Nge bie bê bie wourk, que nous entendissions.
Nge mine bè mine wourk, que vous entendissiez.
Nge bé bè bé wourk, qu'ils entendissent.

PASSÉ DU SUBJONCTIF ET PLUS-QUE-PARFAIT

Nge mé nga wourk, que j'aie entendu.
Nge o nga wourk, que tu aies entendu.
Nge a nga wourk, qu'il ait entendu.
Nge bie nga wourk, que nous ayons entendu.
Nge mine nga wourk, que vous ayez entendu.
Nge bé nga wourk, qu'ils aient entendu.

INFINITIF

PRÉSENT

Ewourk, entendre.

PASSÉ

Kagha wourk, avoir entendu.

PARTICIPE

PRÉSENT

Nge mour a wourk, quelqu'un entendant.

PASSÉ

Emour a kagha wourk, ayant entendu.

Conjuguez ainsi tous les verbes terminés par *rk*.

VERBE **EDJI** (*MANGER*).

Conjuguer ce verbe sur *Eyen* jusqu'à l'Impératif.

IMPÉRATIF

Djark, mange.
Djagha, mangez.

SUBJONCTIF

PRÉSENT

Mé djark, que je mange.
O djark, que tu manges.
A djark, qu'il mange.
Bie adjark, que nous mangions.
Mme adjark, que vous mangiez.
Ba djark, qu'ils mangent.

Voyez *eyen* pour les autres temps.

Conjuguez de même, *egnou*, boire; *ewou*, mourir; *enjou*, venir et plusieurs autres. Tous ces verbes changent à ces temps *i* et *ou* en *ark*.

VERBES PASSIFS

VERBE **EYÉNBA** (*ÊTRE VU*).

INDICATIF

PRÉSENT	IMPARFAIT
Ma yenéba, je suis vu.	*Ma yéyenéba*, j'étais vu.
Wa yenéba, tu es vu.	*Wa yéyenéba*, tu étais vu.
A yenéba, il est vu.	*A yéyenéba*, il était vu.
Bie ayenéba, nous sommes vus.	*Bie yéyenéba*, nous étions vus.
Mine ayenéba, vous êtes vus.	*Mine ayéyenéba*, vous étiez vus.
Ba yenéba, ils sont vus.	*Ba yéyeneba*, ils étaient vus.

PASSÉ DÉFINI

Mé nga yenéba, je fus vu.
O nga yenéba, tu fus vu.
A nga yenéba, il fut vu.

Bie nga yenéba, nous fûmes vus.
Mine nga yenéba, vous fûtes vus.
Bé nga yenéba, ils furent vus.

PASSÉ INDÉFINI

Mé yenéa, j'ai été vu.
O yenéa, tu as été vu.
A yenéa, il a été vu.
Bie yenéa, nous avons été vus.
Mine yenéa, vous avez été vus.
Bé yenéa, ils ont été vus.

PASSÉ ANTÉRIEUR

Mé kagha yenéba, j'eus été vu.
O kagha yenéba, tu eus été vu.
A kagha yenéba, il eût été vu.
Bie kagha yenéba, nous eûmes été vus.
Mine kagha yenéba, vous eûtes été vus.
Bé kagha yenéba, ils eurent été vus.

PLUS-QUE-PARFAIT

Mé mbè mé yenéa, j'avais été vu.
O mbè o yenéa, tu avais été vu.
A mbè a yenéa, il avait été vu.
Bie mbè bie yenéa, nous avions été vus.
Mine mbè mine yenéa, vous aviez été vus.
Bé mbè bé yenéa, ils avaient été vus.

FUTUR

Mé ké yenéba, je serai vu.
O ké yenéba, tu seras vu.
A ké yenéba, il sera vu.
Bie ké yenéba, nous serons vus.
Mine ké yenéba, vous serez vus.
Bé ké yenéba, ils seront vus.

FUTUR ANTÉRIEUR

Mé ké to mé yenéa, j'aurai été vu.
O ké to o yenéa, tu auras été vu.
A ké to a yenéa, il aura été vu.
Bie ké to bie yenéa, nous aurons été vus.
Mine ké to mine yenéa, vous aurez été vus.
Bé ké to bé yenéa, ils auront été vus.

CONDITIONNEL

PRÉSENT

Vé mé yenéba, je serais vu.
Vé o yenéba, tu serais vu.
Vé a yenéba, il serait vu.
Vé bie yenéba, nous serions vus.
Vé mine yenéba, vous seriez vus.
Vé bé yenéba, ils seraient vus.

PASSÉ

Vé mé nga yenéba, j'aurais été vu.
Vé o nga yenéba, tu aurais été vu.
Vé a nga yenéba, il aurait été vu.
Vé bie nga yenéba, nous aurions été vus.
Vé mine nga yenéba, vous auriez été vus.
Vé bé nga yenéba, ils auraient été vus.

IMPÉRATIF

Ba yenéyé wè, sois vu.
Ba yenébé mine, soyez vus.

SUBJONCTIF

PRÉSENT

Ba yenége méne, que je sois vu.
Ba yenége wéni, que tu sois vu.
Ba yenége gne, qu'il soit vu.
Ba yenége bie, que nous soyons vus.
Ba yenége mine, que vous soyez vus.
Ba yenége bo, qu'ils soient vus.

IMPARFAIT

Nge mé mbè mé yenéba, que je fusse vu.
Nge o mbè o yenéba, que tu fusses vu.
Nge a mbè a yenéba, qu'il fût vu.
Nge bie mbè bie yenéba, que nous fussions vus.
Nge mine mbè mine yenéba, que vous fussiez vus.
Nge bé mbé bé yenéba, qu'ils fussent vus.

PASSÉ ET PLUS-QUE-PARFAIT

Nge mé nga yenéba, que j'aie été vu.
Nge o nga yenéba, que tu aies été vu.
Nge a nga yenéba, qu'il ait été vu.

Nge bie nga yenéba, que nous ayons été vus.
Nge mine nga yenéba, que vous ayez été vus.
Nge bé nga yenéba, qu'ils aient été vus.

Le plus-que-parfait s'exprime comme le passé

INFINITIF

PRÉSENT

Eyenéba, être vu.

PASSÉ

Kagha yenéba, avoir été vu.

PARTICIPE

PRÉSENT

Nyéna, vu.

PASSÉ

Mour kagha yenéba, quelqu'un ayant été vu.

Remarque. Au lieu de cette forme passive, on se sert, la plupart du temps, de la forme active avec le pronom indéfini *ba*, on.

Ba yen méne, on me voit, ou je suis vu.
Bé nga gnéghe gne, il a été aimé d'eux.

VERBE **EDJÈBA** (*ÈTRE MANGÉ*).

IMPÉRATIF

Ba djaghe wéni, sois mangé.
Ba djaghe mine, soyez mangés.

SUBJONCTIF

PRÉSENT

Ba djaghe mé, que je sois mangé.
— *wé*, que tu sois mangé.
— *gne*, qu'il soit mangé.
— *bie*, que nous soyons mangés.
— *mine*, que vous soyez mangés.
— *bo*, qu'ils soient mangés.

PARFAIT

Nge mé nga djèba, que j'aie été mangé, etc.

INFINITIF

PRÉSENT

Edjèba, être mangé, etc.

VERBE **EWOUGHEBA** (*ETRE ENTENDU*).

INDICATIF

PRÉSENT

Ma woughéba, etc , je suis entendu, etc.

IMPARFAIT

Ma wouwoughéba, j'étais entendu, etc.

PASSÉ

Mé woughéa, j'ai été entendu (si le temps n'est pas éloigné), etc.
ou *Mé nga woughéba*, s'il est plus éloigné.

PASSÉ ANTÉRIEUR

Mé kagha woughéba, j'eus été entendu.

PLUS-QUE-PARFAIT

Mé mbè mé woughéa, j'avais été entendu.

FUTUR

Mé ké woughéba, je serai entendu.

FUTUR ANTÉRIEUR

Mé ké to mé woughéa, j'aurai été entendu.

CONDITIONNEL

PRÉSENT

Vé mé woughéba, je serais entendu.

PASSÉ

Vé mé nga woughéba, j'aurais été entendu.

IMPÉRATIF

PRÉSENT

Ba woughe wè, sois entendu.
Ba woughe mine, soyez entendus

SUBJONCTIF

PRÉSENT

Ba woughe méne, que je sois entendu,

IMPARFAIT

Ba woughe méne, que je sois entendu.

PARFAIT

Nge mé nga woughéba, que j'aie été entendu

PLUS-QUE-PARFAIT, idem.

INFINITIF

PRÉSENT

Ewoughéba, être entendu.

PASSÉ

Kagha woughéba, avoir été entendu.

PARTICIPE

PRÉSENT

Nwougha, entendu.

PASSÉ

Mour kagha woughéba, q. q. ayant été entendu.

VERBES PRONOMINAUX

Les verbes pronominaux sont de trois sortes.

I. — Les verbes pronominaux de la première sorte sont ceux qui expriment l'action du seul sujet relativement à lui-même, comme s'aimer soi-même; ils s'expriment par *egnoul zam, egnoul zia,* etc.

Exemple. — *Ma gnéghe egnoul zam*, je m'aime.
Wa gnéghe egnoul zia, tu t'aimes.
A gnéghe egnoul zia, il s'aime.
Bie agnéghe mégnoul ma, nous nous aimons.
Mine agnéghe mégnoul mina, vous vous aimez.
Ba gnéghe mégnoul moa, ils s'aiment.

II. — Les verbes pronominaux de la deuxième sorte expriment un acte commun à deux ou plusieurs personnes, à deux ou plusieurs choses :

Exemple. — S'entr'aimer.

INDICATIF

PRÉSENT

Bie agnégha, nous nous aimons.
Mine agnégha, vous vous aimez
Ba gnégha, ils s'aiment.

Remarque. — On dit aussi : *Bie agnéghana*, *Mine agnéghana*, *Ba gnéghana*.

IMPARFAIT

Bie agnignégha, nous nous aimions.
Mine agnignégha, vous vous aimiez.
Ba gnignégha, ils s'aimaient.

PASSÉ

Bie nga gnégha, nous nous sommes aimés.
Mine nga gnégha, vous vous êtes aimés.
Bé nga gnégha, ils se sont aimés.

Et ainsi pour tous les autres temps. La forme *égnéghana* est très souvent usitée, surtout chez les Fangs dont la tribu commence par *ébi*.

Remarque. 1° — Les verbes qui se conjuguent sur *ewourk* se conjuguent aussi sur *égnéghe* quand ils sont pronominaux.
2° La forme suivante est peut-être plus souvent employée que la précedente.

INDICATIF PRÉSENT

Bie agnéghe bie né bie, nous nous aimons.
Mine agnéghe mine né mine, vous vous aimez.
Ba gnéghe bo né bo, ils s'aiment.

Le mot à mot est : nous nous aimons entre nous, vous vous aimez entre vous, ils s'aiment entre eux. On dit aussi :

Bie agnéghe bébien bébien, nous nous aimons.
Mine agnéghe bébien bébien, vous vous aimez.
Ba gnéghe bébien bébien, ils s'aiment.

III. — Les verbes pronominaux de la troisième classe sont ceux que nous appellerons purement pronominaux, c'est-à-dire qui n'expriment que l'action d'un seul sujet relativement à lui-même, comme s'en aller.

INDICATIF

PRÉSENT

Mé bvouléa, je m'en vais, etc.

IMPARFAIT

Mé bvoubvouléa, je m'en allais.

PASSÉ

Mé bvoulana, je m'en suis allé.

FUTUR

Mé ké bvoula, je m'en irai.

IMPÉRATIF

Bvouléga, va-t'en.

SUBJONCTIF

PRÉSENT

Mé bvouléga, que je m'en aille.

PARFAIT

Nge mé bvoulana.

INFINITIF

PRÉSENT

Ebvoula, s'en aller.

PASSÉ

Kagha bvoula, s'en être allé.

PARTICIPE

PRÉSENT

Né bvoula, en s'en allant.

PASSÉ

Mour kagha bvoula, q. q. s'en étant allé.

CHAPITRE VI

Participe.

I. — PARTICIPE PRÉSENT.

Le participe présent s'exprime de plusieurs manières.

1° Par le pronom personnel en prenant la tournure suivante :

Je vois des enfants s'amusant.
Ma yen bone ba vi, mot à mot ils s'amusent.

2° Par l'impératif, en le faisant précéder d'un *a* initial.

Il m'a salué en passant.
A shôs mé alourége a nzen.

3° Par la préposition *né.*

Il est mort en revenant.
A nga wou né bvoule.

4° Par la tournure suivante :

Je l'ai vu en revenant du village.
Mé nga yen gné, mé nga sho é dyal.
Je l'ai vu, je suis venu du village

5° Par la particule *nge.*

Il m'aidera en venant ici.
A ké mé vole nge a njou.

II. — PARTICIPE PASSÉ.

Le participe passé soit actif, soit passif, s'exprime :

1° Par la forme ordinaire : *Mour kagha yen,* q. q. ayant vu. *Nyua,* tué. *Ngnégha,* aimé.

2° Par le pronom personnel, le verbe *être* et le participe *même*.

J'ai vu un homme mangé par les oiseaux.
Mé nga yen mour a ne ndjia n'anon.

3° On se sert aussi de la forme active ainsi que l'on verra dans l'exemple suivant.

Voici mes élus.
Ebour mé nga fè, ébo ba.
Mot à mot. Les hommes que j'ai élus, les voici.

Remarque. — Pour les adverbes, les prépositions, les conjonctions et les interjections, voir le dictionnaire. Nous ne parlerons plus que de l'interrogation et de la négation.

CHAPITRE VII

Interrogation et négation.

INTERROGATION

1° *Pourquoi*, s'exprime par *Ji. Né zè. Yé zè. Nza akale Nza ajou. Nza dzam. E bo zè.*

Pourquoi avez-vous fait cela? *Ji o nga bo ajou déle?*
ou, *O nga bo ajou déle, né zè. O nga bo ajou déle, é bo zè,* etc.

2° *Est-ce que.* On exprime *est-ce que* par *né.*

Est-ce que vous êtes capable de faire cela?
Né o ne ki ebo edzam jéle?

ou bien par *nga,* que l'on renvoie à la fin de la phrase.

Est-ce qu'il est fort? *A ne né ki, nga?*

3° *Comment,* s'exprime par *nza* avec le substantif verbal.

Comment a-t-il fait cela? *A nga bo ejoum jéle nza abo?*

Ou bien par *na.*

Comment a-t-il fait cela? *A nga bo ejoum jéle na?*

Ou bien par *zè.*

A nga bo ejoum jéle zè?

Nous passons sous silence les autres interrogations. On les trouvera dans le dictionnaire.

NÉGATION

Souvent les Fangs n'expriment pas la négation, ou plutôt l'expriment par un geste de lèvres difficile à saisir et à imiter.

J'aime *ma gnéghe*. Je n'aime pas *mū gnéghe*.

L'*a* est un peu allongé, et la première syllabe de *gnéghe* est comme précédée d'un *n*. Nous exprimons cette négation dans l'écriture par un trait placé sur le mot.

Les autres formes de négations sont suffisamment expliquées dans le dictionnaire.

IWE ADURA LATI GBỌ̀ MISA

PẸLU AWỌN EPISTOLI ATI IHIN RERE

TI OJỌ OSẸ KỌKAN, ETC.

IWE ADURA LATI GBỌ́ MISA

PẸLU AWỌN EPISTOLI ATI IHIN RERE

TI ỌJỌ ỌSẸ KỌKAN, Etc.

Nipa L. Bastian

DES MISSIONS AFRICAINES DE LYON

Pẹlu aṣẹ ti Bịsopu Chausse

Vic. apost. Benin.

—

1893



ILANA-ISIN MISSA

In nomine Patris, et Filii, et Spiritus Sancti. Amen.

S. Introibo ad altare Dei.

Id. Ad Deum qui lætificat juventutem meam.

S. Judica me, Deus, et dicerne causam meam de gente non Sancta ab homine iniquo et doloso erue me.

Id. Quia tu es, Deus, fortitudo mea, quare me repulisti, et quare tristis incedo, dum affligit me inimicus ?

S. Emitte lucem tuam et veritatem tuam, ipsa me deduxerunt et adduxerunt in montem Sanctum tuum, et in tabernacula tua.

Id. Introibo ad altare Dei, ad Deum, qui lætificat juventutem meam.

S. Confitebor tibi in citharâ, Deus, Deus meus; quare tristis es, anima mea, et quare conturbas me?

Id. Spera in Deo quoniam adhuc confitebor illi, salutare vultûs mei, et Deus meus.

S. Gloria Patri, et Filio, et Spiritui sancto.

Id. Sicut erat in principio, et nunc, et semper, et insæcula sæculorum. Amen.

S. Introibo ad Altare Dei.

Id. Ad Deum, qui lætificat juventutem meam.

S. Adjutorium nostrum in nomine Domini.

Id. Qui fecit cœlum et terram.

S. Confiteor, etc.

Id. Misereatur tuî omnipotens Deus, et dimissis peccatis tuis, perducat te ad vitam æternam.

S. Amen.

Id. Confiteor Deo omnipotenti, beatæ Mariæ semper Virgini, beato Michaeli Archangelo, beato Joanni Baptistæ, sanctis Apostolis Petro et Paulo, omnibus Sanctis, et tibi, Pater, quia peccavi nimis cogitatione, verbo, et opere, mea culpa, mea culpa, mea maxima culpa. Ideo precor beatam Mariam semper Virginem, beatum Michaelem Archangelum, beatum Joannem Baptistam, Sanctos Apostolos Petrum et Paulum, omnes Sanctos, et te, Pater, orare pro me ad Dominum Deum nostrum.

S. Misereatur vestrì, etc. Id. Amen.
S. Indulgentiam, etc. Id. Amen.
S. Deus tu conversus vivificabis nos.
Id. Et plebs tua lætabitur in te
S. Ostende nobis, Domine, misericordiam tuam.
Id. Et salutare tuum da nobis.
S. Domine, exaudi orationem meam.
Ic. Et clamor meus ad te veniat.
S. Dominus vobiscum.
Id. Et cum spiritu tuo,
S. Kyrie eleison. Id. Kyrie eleison.
S. Kyrie eleison. Id. Christe eleison.
S. Christe eleison. Id. Christe eleison.
S. Kyrie eleison. Id. Kyrie eleison.
S. Kyrie eleison.
S. Dominus vobiscum.
Id. Et cum spiritu tuo.
Lẹhin adura. Id. Amen.
Lẹhin Epistoli. Id. Deo gratias.
S. Dominus vobiscum.
Id. Et cum spiritu tuo.
S. Sequentia sancti Evangeli, etc.
Id. Gloria tibi, Domine.
Lẹhin Efangẹli.
Id. Laus tibi, Christe.

S. Dominus vobiscum.

Id. Et cum spiritu tuo.

S. Orate fratres.

Id. Suscipiat Dominus sacrificium de manibus tuis ad laudem. et gloriam nominis sui, ad utilitatem quoque nostram, totiusque Ecclesiæ suæ sanctæ.

S. Per omnia sæcula sæculorum.

Id. Amen.

S. Dominus vobiscum.

Id. Et cum spiritu tuo.

S. Sursum corda.

Id. Habemus ad Dominum.

S. Gratias agamus Domino Deo nostro.

Id. Dignum, et justum est.

S. Per omnia sæcula sæculorum.

Id. Amen.

S. Et ne nos inducas in tentationem.

Id. Sed libera nos à malo.

S. Per omnia sæcula sæculorum.

Id. Amen.

S. Pax Domini sit semper vobiscum.

Id. Et cum spiritu tuo.

Lẹhin adura. Id. Amen.

S. Dominus vobiscum.

Id. Et cum spiritu tuo.

S. Ite, Missa est (tabi) Benedicamus Domino.

Id. Deo gratias.

S. (Ni Missa awọn okú) Requiescant in pace.

Id. Amen.

S. Benedicat vos omnipotens Deus, Pater, et Filius, et Spiritus Sanctus.

Id. Amen.

S. Dominus vobiscum.

Id. Et cum spiritu tuo.

S. Initium (tabi) Sequentia sancti Evangelii secundum, etc.

Id Gloria tibi, Domine.
Lẹhin Efangẹli ti ikẹhin.

Id. Deo gratias.

Ifihàn akoko gán ti awọn

Anno Dom.	Litt. Dom.	Aureus numer.	Epact.	Septuagesima.	Dies Cinerum.	Pascha.
1894	g	14	xxiii	21 Jan.	7 Febr.	25 Mart.
1895	f	15	iv	10 Febr.	27 Febr.	14 Apr.
1896	e d	16	xv	2 Febr.	19 Febr.	5 Apr.
1897	c	17	xxvi	14 Febr.	3 Mart.	18 Apr.
1898	b	18	vii	6 Febr.	23 Febr.	10 Apr.
1899	A	19	xviii	29 Jan.	15 Febr.	2 Apr.
1900	g	1	xxix	11 Febr.	28 Febr	15 Apr.
1901	f	2	x	3 Febr.	20 Febr.	7 Apr.
1902	e	3	xxi	26 Jan.	12 Febr.	30 Mart.
1903	d	4	ii	8 Febr.	25 Febr.	12 Apr.
1904	c b	5	xiii	31 Jan.	17 Febr.	3 Apr.
1905	A	6	xxiv	19 Febr.	8 Mart.	23 Apr.
1906	g	7	v	11 Febr.	28 Febr.	15 Apr.
1907	f	8	xvi	27 Jan.	13 Febr.	31 Mart.
1908	e d	9	xxvii	16 Febr.	4 Mart.	19 Apr
1909	c	10	viii	7 Febr.	24 Febr.	11 Apr.
1910	b	11	xix	23 Jan.	9 Febr.	27 Mart
1911	A	12	« »	12 Febr.	1 Mart.	16 Apr.
1912	g f	13	xi	4 Febr.	21 Febr.	7 Apr.
1913	e	14	xxii	19 Jan.	5 Febr.	23 Mart
1914	d	15	iii	8 Febr.	25 Febr.	12 Apr.
1915	c	16	xiv	31 Jan.	17 Febr.	4 Apr.
1916	b A	17	25	20 Febr.	8 Mart.	23 Apr.
1917	g	18	vi	4 Febr.	21 Febr.	8 Apr.

Odún Mimó ti ma yipada.

Anno Dom.	Ascensio.	Pentecostes.	Corpus Christi.	Indictiones.	Domin. p. Pent.	Dominica prima Advent.
1894	3 Maji	13 Maji	24 Maji	7	28	2 Déc.
1895	23 Maji	2 Junii	13 Junii	8	25	1 Dec.
1896	14 Maji	24 Maji	4 Junii	9	26	29 Nov.
1897	27 Maji	6 Junii	17 Junii	10	24	28 Nov
1898	19 Maji	29 Maji	9 Junii	11	25	27 Nov
1899	11 Maji	21 Maji	1 Junii	12	27	3 Déc.
1900	24 Maji	3 Junii	14 Junii	13	25	2 Déc.
1901	16 Maji	26 Maji	6 Junii	14	26	1 Déc.
1902	8 Maji	18 Maji	29 Maji	15	27	30 Nov.
1903	21 Maji	31 Maji	11 Junii	1	25	29 Nov.
1904	12 Maji	22 Maji	2 Junii	2	26	27 Nov.
1905	1 Junii	11 Junii	22 Junii	3	24	3 Déc.
1906	24 Maji	3 Junii	14 Junii	4	25	2 Déc.
1907	9 Maji	19 Maji	30 Maji	5	27	1 Déc.
1908	28 Maji	7 Junii	18 Junii	6	24	29 Nov.
1909	20 Maji	30 Maji	10 Junii	7	25	28 Nov.
1910	5 Maji	15 Maji	26 Maji	8	27	27 Nov.
1911	25 Maji	4 Junii	15 Junii	9	25	3 Déc.
1912	16 Maji	26 Maji	6 Junii	10	26	1 Déc.
1913	1 Maji	11 Maji	22 Maji	11	28	30 Nov.
1914	21 Maji	31 Maji	11 Junii	12	25	29 Nov.
1915	13 Maji	23 Maji	3 Junii	13	26	28 Nov.
1916	1 Junii	11 Junii	22 Junii	14	24	3 Déc.
1917	17 Maji	27 Maji	7 Junii	15	26	2 Déc.

ADURA OWURỌ

L'orukọ Baba, ati Ọmọ, ati Ẹmi-Mimọ. Amin.

Ọlọrun mi, mo gbagbọ pe Iwọ wà nibigbogbo ati nihinyi nisisiyi. Mo foribalẹ niwaju rẹ, nitori Iwọ l'elẹdá mi ati Oluwa mi.

Mo dupẹ lọwọ rẹ, nitori Iwọ ti dá mi, rà mi pada, ati sọ mi di kristiani, nitori gbogbo ôre ti Iwọ ti ṣe fun mi nigbagbogbo, ati itori ti Iwọ ti pa mi mọ lalafia l'oru yi.

Ọlọrun mi, mo bẹ Ọ, k'o pa mi mọ kuro ninu ẹṣẹ ati buburu gbogbo. Fun mi l'ôre-ọfẹ rẹ ki má ṣe ohun t'o lè ba Ọ ninu jẹ; k'o si jẹ ki mbẹru rẹ nigbagbogbo, ati ki ọrọ ẹnu mi, ironu ọkàn mi ati iṣẹ ọwọ mi ki o jẹ mimọ, ati itẹwogba niwaju rẹ. Gbà adura mi yi, Oluwa mi, k'o si fun mi l'ohun rere gbogbo t'emi nṣe alaini, fun ara mi ati fun ọkàn mi lati mọ, lati fẹ, ati lati sìn Ọ loni, ati nijọ aiyé mi gbogbo, ati ki lehin ikú mi, ki mba lè de ọdọ rẹ lati jẹ alafia ti kò nipẹkun. Amin.

BABA WA, Etc.

Baba wa, ti mbẹ l'ọrun; ọwọ l'orukọ rẹ; ijọba rẹ de; ifẹ ti rẹ ni k'a ṣe l'aiyé, bi nwọn ti nṣe l'ọrun.

Fu wa l'onjẹ ojọ wa l'òni; dari ẹṣẹ wa jì wa, bi a ti ndari ẹṣẹ jì awọn t'o ṣẹ wa; má fà wa sinu idanwò; ṣugbọn gbà wa kuro ninu tulasin Amin.

IKÍ ANGẸLI

Mo ki Ọ Maria, O kún fun ôre-ọfẹ́, Oluwa mbẹ pẹlu rẹ; alabukún fun ni Iwọ ninu awọn obiri, alabukún fun sì ni eso inu rẹ, Jesu.

Maria mimọ, Iyá Olorun, gbàdua fun wa, otọsi ẹlẹṣẹ, nisisi, ati l'akokò ikú wa. Amin.

SIMBOLI

Mọ gbà Olorun Baba Olodumare gbọ́, Ẹlẹdá orun on aiyé; mo gbà Jesu-Kristi gbọ́, Ọmọ rẹ̀ kanṣoṣo, Oluwa wa, Ẹni t'a fi Ẹmi-Mimọ́, l'oyún, Ẹni t'a bí ninu Maria Wundia; Ẹni t'o jiya l'ọwọ́ Pontiu. Pilatu, Ẹni t'a kàn mọ́ agbelebu, Ẹni t'o kú, t'a sì sin; O sọkalẹ rẹ̀ ipò okú; n'ijọ́ kẹta, O tun jinde kuro ninu okú; O rẹ̀ oke orun; O sì joko l'ọwọ́ ọtún Olorun Baba Olodumare; nibẹ̀ ni yio gbé ti padà wá ba àye on okú wijọ.

Mo gbà Ẹmi-Mimọ́ gbọ́; ati Eklesia katolika Mimọ́; ati idápọ awọn enia-mimọ́; idarijì ẹ̀ṣẹ; ajinde ara nisà okú; ati ìye ti kò nipẹkun. Amin.

OFIN OLORUN

Iwọ kò gbọdọ l'Olorun mì niwaju mi. Iwọ kò gbọdọ ya erekere fun ara rẹ, tabi aworan nkan ti mbẹ l'oke orun, tabi ti nkan ti mbẹ nisalẹ ilẹ, tabi ti nkan ti mbẹ ninu omi nisalẹ ilẹ; iwọ kò gbọdọ bọ wọn, bẹ̀ni iwọ kò gbọdọ sìn wọn.

Iwọ kò gbọdọ pè orukọ Olọrun rẹ lasan.
Ranti lati pa ijọ Oluwa mọ ni mimọ.
Bọwọ fun baba on iyá rẹ.
Iwọ kò gbọdọ pa enia.
Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.
Iwọ kò gbọdọ jale.
Iwọ kò gbọdọ jẹri eke si ẹnikeji rẹ.
Iwọ kò gbọdọ ṣ'oju kokoro si obiri ẹnikeji rẹ.
Iwọ kò gbọdọ ṣ'oju kokoro s'ohun ẹnikeji rẹ.

OFIN EKLESIA

Pa ijọ Oluwa ati ti Eklesia mọ ni mimọ.

Jẹwọ èṣẹ rẹ, b'o ti wù k'o ri, l'ẹkan lọdún.

Gbà ara Jesu-Kristi, nipataki, nigba Paska.

Gbawẹ nigba kuadragesima (lenti), ati ninu awọn akoko mẹrin tọdún, ati ninu awọn ọjọ vigili.

Iwọ kò gbọdọ jẹran nijọ kẹfa ọṣẹ.

Dà owo silẹ fun iranlọwọ awọn saserdoti.

Iwọ kò gbọdọ gbeyawo laigbà sakramenti matrimoni, tabi l'akoko t'a da lẹkun, tabi ninu ọṣẹ melo kan ti ibatan-ẹni t'a kilọ fun, tabi lọnakọna ti Eklesia kò gbà.

LITANI TI ORUKỌ, MIMỌ TI JESU

Oluwa, ṣânu fun wa.
Kristi, ṣânu fun wa.
Oluwa, ṣânu fun wa.
Jesu, gbọ́ tiwa.
Jesu, gbà adura wa.

Ọlọrun, Baba ọrun.
Ọlọrun Ọmọ, Olurapada aiye.
Ẹmi-Mimọ́, Ọlọrun.
Mẹtalọkan-Mimọ́, Ọlọrun kan
Jesu, Ọmọ Ọlọrun alàye.
Jesu, idarasaka ti Baba.
Jesu, irandidara ti imọlẹ ainipẹkun.
Jesu, ọba ogo.
Jesu, ôrun ododo.
Jesu, ọmọ Maria Wundia.
Jesu, oninure.
Jesu, oniyanu.
Jesu, Ọlọrun alagbara.
Jesu, Baba aiye ti mbọ̀
Jesu, angẹli ti igbimọ̀ pipe.
Jesu, alagbara julọ.
Jesu, onisûru julọ.
Jesu, oniteriba julọ.
Jesu, oninu tùtu ati titẹ.
Jesu, olufẹ̀ iwa mimọ́.
Jesu, olufẹ̀ wa.
Jesu, Ọlọrun alafia.
Jesu, Baba ìye.
Jesu, alapẹrẹ iwa mimọ́ gbogbo.

Jesu, olusoji emi wa.
Jesu, Olorun wa.
Jesu, âbo wa.
Jesu, Baba awon otosi.
Jesu, isura awon olotito.
Jesu, olusó rere.
Jesu, imole tôto.
Jesu, ogbon ainopin.
Jesu, iseun ailala.
Jesu, ona ati iye wa.
Jesu, ayò awon angeli.
Jesu, olukó awon apostoli.
Jesu, akógbón awon efangelisti.
Jesu, agbara awon martiri.
Jesu, imole awon olujewó igbagbó.
Jesu, iwa mimó awon wundia.
Jesu, âdé enia mimó gbogbo.

Se sùru , dari ji wa, Jesu.
Se sùru, gbà adura wa, Jesu.

Ninu ibi gbogbo.
Ninu èsè gbogbo.
Ninu ibinu re.
Ninu idanwò èsu.
Ninu emí pansaga.
Ninu ikú ainipekun.
Ninu imole imisi re.
Nipa misteri inkarnasioni mimó re.
Nipa ibí re.
Nipa igba ewé re.
Nipa iye re bi-Olorun.
Nipa awon ise re.
Nipa iwaya-ija ati ijiya re.

Sàanu fun wa.

Gbà wa là, Jesu.

Nipa agbelebu ati ikọsilẹ rẹ.
Nipa awọn ihanujẹ rẹ.
Nipa ikú ati isìn rẹ.
Nipa ajinde rẹ.
Nipa igoke rè ọrun rẹ.
Nipa awọn ayọ rẹ.
Nipa ogo rẹ.

Ọdọ-agutan Ọlọrun t'o kó ẹṣẹ aiye lọ.
Dari ẹṣẹ wa ji wa, Jesu.
Ọdọ-agutan Ọlọrun t'o kó ẹṣẹ aiye lọ.
Gbà adura wa, Jesu.
Ọdọ-agutan Ọlọrun t'o kó ẹṣẹ aiye lọ.
Sãnu fun wa, Jesu.
Gbọ́ ti wa, Jesu.
Gbà adura wa, Jesu.

Adura.

Oluwa Jesu-Kristi, Iwọ ti wìpe: Bère, ao sì fifun nyin; Wá kiri, enyin o sì ri; kankùn, ao sì ṣi i silẹ fun nyin; awa mbẹ Ọ, fifun wa li itara si ifẹ rẹ mimọ, k'a ba lè fi gbogbo ọkàn, enu ati iṣe wa ṣe ifẹ rẹ nitõtọ, k'a sì ba lè yìn Ọ l'aisimi. Amin.

Olnwa, jẹ k'a bẹru, k'a sì fẹ oruko rẹ mimọ nigbagbogbo, nitoripe Iwọ kò ti kọ silẹ ri, awọn eniti nkẹgbẹ ifẹni rẹ.

ADURA SI ANGẸLI OLUTỌJU

Angẹli mimọ, olutọju mi olotitọ, fi imọlẹ fun mi l'oni yi, ṣọ mi, dari mi, k'o sì ran mi l'owọ́ nigbakugba. Amin.

ANGẸLUS

Angẹli Ọluwa jiṣẹ fun Maria.
Ati on yún nipa agbara Ẹmi-Mimọ́.
Mo kí Ọ Maria, etc.

Sa wò ọmọbiri Ọdọ Oluwa.
K'o ri fun mi gẹgẹ bi Ọrọ rẹ.
Mo kí Ọ Maria etc.

A sì sọ Ọro dì ara.
On sì mba wa gbé.
Mo kí Ọ Maria, etc.

℣ Gbadura fun wa, iyá mimọ́ Ọlọrun.
℟ Ki awa lè yẹ lati jẹ alabapin ninu awọn ileri Kristi.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, tú ôre ọfẹ rẹ sinu ọkàn wa, ki awa, t'o ti mọ̀ isọdi enia ti Jesu-Kristi Ọmọ rẹ, nipa iṣẹ́riran ti Angẹli kan, ki a lè de nipa itoye ijiya ati agbelebu rẹ, si ibi ogo ajinde; nitori J.K. kannâ, Oluwa wa. Amin.

Adura nisaju Onjẹ.

Bukún fun wa, Oluwa, ati fun onjẹ ti awa fẹ jẹ. L'orukọ Baba, etc.

Idupẹ-lẹhin onjẹ: Awa dupẹ l'ọwọ́ rẹ, Ọlọrun olodumare, nitori gbogbo ôre ati iṣeun rẹ fun wa; Iwọ t'o wà, t'o sì jọba, aiye ainipẹkun. Amin.

Nipa ânu Ọlọrun ki ẹmi awọn olododo t'o ṣe alaisi, lè simi l'alafia. Amin.

ADURA ALẸ

Ọlọrun mi, mo gbagbọ pe Iwọ wà nibigbogbo ati nihinyi nisisiyi. Mo foribalẹ niwaju rẹ, nitori Iwọ l'Ẹlẹdá mi ati Oluwa mi. Mo dupẹ l'ọwọ rẹ, nitori Iwọ ti dá mi, rà mi pada, sọ mi di kristiani; nitori gbogbo ôre ti Iwọ ti ṣe fu mi nigbagbogbo at'itori Iwọ ti pa mi mọ l'alafia l'oni.

Jẹ ki uranti èṣẹ mi:

Mo jẹwọ fu Ọlọrun Olodumare, fu Maria alabukún, lailai wundia, fu Mikaeli alabukún olori awọn Angẹli, fu Joanni-Batisti alabukún, fu awọn apostoli mimọ Pitẹru on Paulu, fu gbogbo awọn enia mimọ (ati fu Iwọ Baba), pe mo ti d'èṣẹ pupọ nipa irònu, nipa ọ̀rọ ati nipa iṣẹ; ijẹbi mi ni, ijẹbi mi ni, ijẹbi nlanlá mi ni, nitori nâ ni mo bẹ Maria alabukún, lailai wundia, Mikaeli alabukún olori awọn Angẹli, Joanni-Batisti alabukún, awọn apostoli mimọ Pitẹru on Paulu, gbogbo awọn enia mimọ (ati Iwọ Baba) k'ẹyin k'o gbadua l'ọdọ Oluwa Ọlọrun wa fu mi.

K'Ọlọrun Ọlodumare k'o ṣânu fu wa, k'o dari èṣẹ jì wa, k'o sì mu wa de inu aiye ti kò nipẹkun. Amin.

K'Oluwa Olodumare ati Alânu julọ, k'o fi fu wa ni idàriji, ìfiji ati imukurò èṣẹ wa. Amin.

Ọlọrun mi, mo bẹ Ọ k'o pa mi mọ ninu èṣẹ ati buburu gbogbo l'oru yi; mo fi ara mi, ati ọkàn mi le Ọ l'ọwọ,

Oluwa mi, jẹ k'Angẹli rẹ mimọ k'o wà pẹlu

mi, k'èṣu k'o má l'agbara l'orí mi, k'o sì jẹ́ k'emi k'o wà, k'emi k'o sì kú l'oju rere niwaju rẹ, ki mba lè de ọdọ rẹ jẹ alafia ainipẹkun.

Oluwa gbà adua mi, k'o sì fi oju rere wò awọn t'o bí mi, awọn olori ati ibatan mi, olórẹ, ọrẹ́, ati ọtá mi pẹlu gbogbo awọn t'emi kò lè ṣaimagbadua fu.

Oluwa mi, pa gbogbo wọn mọ́, k'o mu buburu gbogbo kuro l'ọdọ wọn, k'o sì fu wọn ni ilera at'alafia ni gbogbo ijọ́ aiyé wọn ; ati l'ẹhin ikú, k'o mu wọn wá de ọdọ rẹ jẹ alafia ti kì yio nipẹkun. Amin.

Baba wa ti mbẹ l'ọrun, etc.

Mọ ki Ọ Maria, etc.

Mọ gbà Ọlọrun Baba Olodumare gbọ́, etc.

IṢE IGBAGBỌ

Ọlọrun mi, gbogbo eyi ti Eklesia katolika Mimọ́ gbàgbọ́, t'o sì nkọ́ wa, l'emi sì gbàgbọ́ tọkàntọkàn, nitori Iwọ ti ṣe otitọ́ pàpà. T'o ti fi hàn fù.

IṢE IRETI

Ọlọrun mi, mo fi igbọkànle girigiri, nreti òre-ọfẹ́ rẹ l'aiyé yi ati ogo rẹ l'aiyé ti mbọ̀ nipa itoye Jesu-Kristi, nitori Iwọ ti ṣe ileri wọn, Iwọ a sì ma ṣe olõtọ ninu ileri rẹ.

IṢE IFẸNI

Ọlọrun mi, mo fi gbogbo aiya mi, ati gbogbo ọkàn mi, ati gbogbo agbara mi fẹ́ Ọ jù ohun gbogbo lọ, nitori Iwọ a ma dara jù gbogbo lọ, ati nitori rẹ mo fẹ́ ẹnikeji mi bi ara mi.

IṢE IKÂNU-ẸṢẸ

Ọlọrun mi, tọkàntọkàn l'emi nkànu gbogbo ẹṣẹ mi ti mo ti ti bà Ọ ninu jẹ; nitori Iwọ a ma dara jù gbogbo lọ, ti Iwọ si ma korira ẹṣẹ patapata; mo pinu girigiri, nipa iranlọwọ ôre ofé rẹ, lati má tún ba Ọ ninu jẹ mọ ati lati ṣe iṣẹ ètutu.

Baba wa, etc. mọ kí Ọ Maria, etc.

Pitẹru on Paulu Mimọ, gbàdua fun wa.

LITANI TI MARIA MIMỌ

Oluwa, ṣânu fun wa.
Kristi, ṣânu fun wa.
Oluwa, ṣânu fun wa.
Kristi, gbọ́ tiwa.
Kristi, gbà adura wa.

Ọlọrun, Baba orun, ṣânu fun wa.
Ọlọrun Ọmọ, Olurapada aiye, ṣânu fun wa.
Ẹmi-Mimọ, Ọlọrun, ṣânu fun wa.
Metalọkan-Mimọ, Ọlọrun kan, ṣânu fun wa.
Maria mimọ
Iyá mimọ Ọlọrun
Wundia mimọ ninu awọn wundia
Iyá Kristi
Iyá ôre-ofe bi-Ọlọrun
Iyá mimọ julọ
Iyá oniwa pipe julọ
Iyá nigbagbogbo Wundia
Iyá ailèri
Iyá olufé

Gbadua fun wa.

Iyá oniyânu
Iyá ti Ẹlẹdá
Iyá ti Ólugbala
Wundia ọlọyé julọ
Wundia ọlọlà
Wundia olokiki
Wundia alagbara
Wundia alânu
Wundia olotitọ
Digi ti ododo
Ibujoko ti ọgbọn
Idi ayọ wa
Ohun elo ẹlẹmi
Ohun elo oniyebiye
Ohun elo olufọkansin julọ
Itaná ijinlẹ
Ile ẹṣọ ti Dafidi
Ile ẹṣọ t'a fi ehín erin kọ
Ile t'a fi wura kọ
Okọ majẹmu
Ilẹkun ọrun
Irawọ kutukutu owurọ
Ilera awọn alaisan
Abo awọn ẹlẹṣẹ
Olutunu awọn onibanujẹ
Iranlọwọ awọn kristiani
Olori awọn angẹli
Olori awọn patriarki
Olori awọn woli
Olori awọn apostoli
Olori awọn martiri
Olori awọn olujẹwọ igbagbọ
Olori awọn wundia
Olori enia-mimọ gbogbo

Ayaba t'a loyún laisi ẹ̀ṣẹ̀ akọṣẹ̀, Gbahua, etc.
Ayaba ti rosario mimọ́ julọ, Gbadua, etc.

Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ,
Dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wa Oluwa.
Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ,
Gbà adura wa Oluwa.
Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'ọ kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ,
Ṣànu fun wa.
Kristi gbọ́ tiwa.
Kristi gbà adura wa.

MEMORARE

Maria Wundia olinure julọ, ranti pe Iwọ kò ti kọ silẹ ri rara, ẹnikẹni t'o sapamọ lọdọ rẹ, t'o sì tọrọ ânu, âbo tabi iranlọwọ́ rẹ. Èmi nâ otoṣi, pẹlu ibanujẹ mo tọ Ọ wá, Iyá mi, wundia awọn wundia, ni dâju tán pe, Iwọ yio ṣe kà ẹ̀bẹ on adua mi si.

Iyá Jesu, má ṣ'aifi etí on ojure rẹ si mi. Amin.

Ib. Gbadua fun wa, Iyá mimọ́ Ọlọrun.
Id. Ki a ba lè yẹ fun ileri Kristi.

Adura

Alagbara gbogbo ati aiyeraiye Ọlọrun, Iwọ ẹniti, pẹlu ajumọṣe Ẹmi-Mimọ́, ti mura tẹlẹ ara ati ọkàn ti Wundia ologo Iyá Maria si ile yiyẹ fun Ọmọ rẹ nì, mu ki, bi a ti fi ayọ́ ranti Maria nisisiyi, ki a ba lè, nipa anfani ẹ̀bẹ rẹ, yọ́ kuro l'ọwọ́ buburu gbogbo ati ikú ainipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Ọkanmâ. Amin.

Ṣavieri mimọ́. Gbadua fun wa
Baba wa, etc. Mo kí Ọ Maria, etc.

IṢẸ OJỌ TI KRISTIANI

Ib Kil'o ye ki iwọ tete koṣe nigbati Iwọ ji l'owurọ.

Id. 1° O ye k'emi ṣe àmi agbelebu, k'emi sì gbà adura kukuru kan, gẹgẹ bi : Olọrun mi, mo fi aiya ati ọkàn mi fun Ọ ; 2° O ye k'emi fi iyara dide, k'emi sì fi imojusá ati tọwọtọwọ wò aṣọ mi, lẹhin eyi o tọ k'emi kunlẹ lati kà adura owurọ mi ; 3° O ye k'emi gbọ́ misa, bi mo ba ri àye, nitori kò si iṣẹ ifọkansìn kan t'o dara, t'o sì l'anfani jù gbigbọ́ misa lọ ; 4° O sì dara fun mi lati ṣe aṣaro niti ikú, idajọ, ọrun rere, ọrun apâdi, ati niti aiyé on ijiya Oluwa J.-K

Ib. O ye, ki iwọ kà iwe rere nigbakugba bi?

Id. Bẹ́ni. 1° O ye k'emi kà iwe rere, gẹgẹ bi iwe mimọ́, iwe itàn aiyé ti awọn enia mimọ́, ati iwe rere mì, t'o lè bọ́ igbagbọ́ ati ifọkansìn mi, t'o sì je ihamọra fun mi si ẹkọkẹkọ́ t'aiye yi ; 2° O sì ye k'emi lò ohun jijẹ́, ohun mimu ati ire ṣiṣe lairekoja, ati pẹlu ifẹ́ lati wù Ọlọrun, ati nipa gbigba adura nipilẹṣẹ ati ni ipari wọn.

Ib. Bawo l'o ti ye k'iwọ sọ iṣẹ òjọ rẹ di mimọ́ ?

Id. 1° O ye k'emi sọ wọn di mimọ́ nipa gbigbé ọkàn mi soke si Olọrun nigbati mo nṣe wọn lọwọ́, ati nipa gbigba adura kukuru kan si I ; 2° Nigbati èṣu ndan mi wò lati dẹṣẹ, o sì ye k'emi ṣe àmi agbelebu, k'emi sì kigbe pè Olọrun, wipe : Olọrun, gbà mi là, bikoṣe bẹ́, mo ṣegbe ; 3° Bi mo ti ṣubu s'inu èṣẹ, o ye k'emi fi ironu wolẹ lẹba ẹṣẹ J.-K., k'emi sì fi irẹlẹ ọkàn bère idariji lọwọ́ rẹ nipa kikà iṣe

ikânu èsẹ tọkântọkàn ; 4° Nigbati Ọlọrun ba ran ìpọnju, aisan tabi ijiya kan si mi, o tún yẹ k'emi wipe ; Oluwa, ṣe gẹgẹ bi ifẹ rẹ, mo gbà nkan yi nitori èsẹ mi ; 5° Lakoko ojọ o yẹ k'emi kà nigbakugba adura t'a bùn indulgensi si, gẹgẹ bi : Ogo ni fun Baba, etc. Jesu, sânu fun mi ; Maria mimọ́ ran mi lọwọ́.

Ib. Bawo l'o yẹ k'iwọ pari ọjọ rẹ ?

Id. O yẹ k'emi pari ọjọ mi nipa kikunlẹ ati kikà adura alẹ mi, lẹhinnà, o yẹ k'emi lọ dubulẹ tọwọtọwọ, k'emi ranti ikú, k'emi sì fi ọkàn mi le Ọlọrun lọwọ́.

ADURA LẸHIN MISA

Mo kí Ọ Maria (ter).

Salve Regina. A kí Ọ, ayâba mimọ́, iyá wa alânu ; a kí Ọ gidigidi. Iwọ jẹ ìye, idi ayọ̀ ati ireti wa. A kepè sì Ọ, awa otoṣi arìnnà ọmọ ti Ẹfa. A kigbe si Ọ nà, pelu ibanujẹ ati omije, ninu afonifoji imi-ẹdùn yi. Njẹ, alagbawi wa, fi oju ânu rẹ wò wa : ati nigbẹhin àjo-ero wa, sá fihàn wa ni Jesu alabukún-fun eso inu rẹ. Nitori ânu ni tirẹ, iṣeun ni tire, inure ni tirẹ. O Maria Wundia.

Adura

Ọlọrun olupamọ́ ati agbara wa, fi ojure wò awọn enia rẹ ti nke pè si Ọ ; k'o sì f'eti ânu on iṣeun rẹ si adura t'a ngbà fun yiyipadà awọn ẹlẹṣẹ ati fun ommira ati igbegá ti Ẹklesia mimọ́ iyá wa. A mbẹ Ọ, nipa ẹbẹ Maria, iyá

Jesu, Wundia ologo ati alailẹṣẹ; nipa ẹbẹ Josefu mimọ́, ọkọ rẹ; nipa ẹbẹ awọn apostoli Piteru on Paulu, ati ti gbogbo awọn enia mimọ́; nitori Jesu Kristi Oluwa wa Amin.

Mikaeli arkangẹli, ṣọ́ wa l'oju ijà : gbà wa là lọwọ́ odi ati idanwò ẹṣu; ṣe sùru, a mbẹ Ọ; ki Ọlọrun ki O kilọ fun u. Iwọ nâ, olori awọn ọmọ-ogun ọrun, l'agbara Oluwa, lé ẹṣu, ti on ti awọn ẹgbẹ rẹ Buburu iyokùu, kuro lọ s'ọrun-apâdi, awọn ti nrin kakiri aiyé fun egbé awọn ọkàn wa Amin.

Adura t'a kà nikunlẹ niwaju agbelebu, lọna eyiti a lè fi jère indulgensi ti gbogbo ẹṣẹ wa nipa aṣẹ Papa mimọ́ Pius IX. 11 Déc. 1846.

Wò o, ni ikunlẹ ati ni itara ọkàn mi ni mo wà niwaju rẹ, Jesu rere ati olufẹ julọ, mo mbẹ Ọ, mo sì tun mbẹ Ọ, ki Iwọ fi oju rere tẹmọ́ gidigidi ninu ọkàn mi, igbagbọ́ âye, ireti lile, ifẹni gbigbona ati ikânu tôtọ́ ti gbogbo ẹṣẹ, pẹlu ipinnu lati tun iwahù b'o ti yẹ; nisisiyi ti mo fi ifẹ nla ati ibanujẹ kikoro ṣe aṣaro jijinlẹ ti awọn ọgbẹ rẹ mararun, ti mo sì nwoye awọn ọrọ ti woli Dafidi fi ẹnu rẹ sọtẹlẹ nigbani, pè : Nwọn dà awọn ọwọ́ mi ati ẹsẹ mi lù; nwọn sì kà gbogbo egungun mi.

ADURA SI ẸMI-MIMỌ

Lati tọrọ iṣẹgun lori ibẹru enia. Fun ijọ Konfirmasi tabi ijọ iranti rẹ.

Ẹmi-Ọlọrun, Iwọ t'o ti sọ mi di kristiani pipẹ l'oni yi, ba mi gbé lati rau ailera mi l'owọ si awọn ọtá akọlù igbala mi; ma jẹ ki nkan ilodi si aworan Jesu-Kristi t'o ti fi sinu ọkàn mi, k'o wà li ironu, l'ifé mi, l'ọrọ tabi l'iṣe mi A, bi Iwọ kò ba ti mi lẹhin, mba ti tete ba àmi nâ jẹ! Eṣu pẹlu odi rẹ, aiyé pẹlu ẹlẹya rẹ, ati ifẹ buburu ọkàn mi, nwọn fẹ ṣigun pọ si mi lati pa ifẹ rẹ run l'aiya mi. Iwọ, Ẹmi-Mimọ, t'o nri èwu t'o yi mi ká, t'o sì ti mu mi ṣe ajagun Jesu-Kristi, gbé ibẹru asán kuro l'odọ mi, ki mba lè bẹru Ọlọrun, t'on ti èṣe nikan. Bi mo ba dojutì Ọ, mba ti ṣ'ojo ati alaimôre pupọ julọ. Iwọ nikan lè ṣe Oluwa, ọba, olòre ati baba mi. Aiyé kò ni lè ṣe ibi tabi ire fun mi. Ṣugbọn Iwọ fẹ da mi l'ẹbi tabi l'àre gẹgẹ bi iṣe mi. Nitorinâ mo pinnu lati tẹle Ọ nigba- gbogbo titi di ijọ ikú mi. Amin.

ADURA NIṢAJU IJẸWỌ ẸṢẸ

Ọlọrun alânu, mo mbẹbẹ lodọ rẹ, fun mi li iranlọwọ ôre-ọfẹ rẹ lati mọ, lati kànu ati lati jẹwọ èṣe mi, bi o ti yẹ, l'odọ saserdoti nipasẹ ẹniti, Iwọ ti ṣileri pe, Iwọ o tú li ọrun gbogbo nkan ti on o sì tú l'aiyé.

IWÀDI ỌKÀN

Ẹṣẹ si Ọlọrun : Aiṣe iṣẹ tabi ijafara lati ṣe iṣẹ wa s'Ọlọrun ; aibọwọ tabi ainirẹlẹ n'ile Ọlọrun, aimojusá, ailiyesi-ifẹ, aigbẹkẹle, ainisùru

Ẹṣẹ si ẹnikeji wa : Idajọ airotẹlẹ, ẹgan, ikorira, ojukokoro, igbẹsan, ija atojudi, isọrọ ni buburu lẹhin, idapara, eké, iba ẹni l'oruko tabi l'ohun-ini rẹ je, apẹrẹ buburu, skandali, aibọwọ fun, aigbọran, ainifẹni.

Si ara wa tikalawa : Igberaga, ogo asán, iberu enia, eké ; iromu ifẹ, ọro tabi iṣe ilodi si iwà mimọ ; aṣeju ninu ohun jijẹ tabi mimu, ainisùru, ọlẹ tabi ilọra ninu iṣẹ-ẹni.

Iṣe ikânu èṣẹ

Olọrun mi, tokàntokàn l'emi nkànu gbogbo èṣẹ mi ti mo fi ba O ninu je, nitori Iwọ ma dara jù ohun gbogbo lọ, ti Iwọ sì ma korira èṣẹ patapata. Mo pinnu girigiri, nipa iranlọwọ ôre-ọfẹ rẹ, lati ma tún ba O ninu je mọ, ati lati ṣe iṣẹ ètutu.

AWỌN IṢE SIWAJU GBIGBÀ KOMUNIONI MIMỌ

Iṣe igbagbọ ati ireti

Oluwa mi Jesu-Kristi, mo gbagbọ tokàntokàn pe emi o gbà ara rẹ, èje rẹ, ati Iwà-

Olọrun rẹ nisisiyi ninu Komunioni mimọ. Mo gbà nkan yi gbọ, nitori Iwọ l'O wí bẹ, o sì yá mi lati kú fun itẹnumọ otitọ yi. Mo sì ni ireti pe ânu rẹ yio fun mi ni gbogbo ôre-ọfẹ ati ẹbun, ti Iwọ mà tifun awọn ẹniti o fi imọ ìgbagbọ́ alàye ati igbẹkẹle girigiri gbà Ọ.

Ìṣe ìrẹlẹ

Oluwa mi Jesu-Kristi, bawo li emi o ti ṣe lè sunmọ ọdọ rẹ, lehin igbati mo ti ṣẹ Ọ nigba pupọ tobẹ? Mo fi ohun irẹlẹ jẹwọ pe, emi kò yẹ ki Iwọ ba wọ inu ọkàn mi, ṣugbọn sọ kiki ọ̀rọ nikan, a o sì mu ọkàn mi laradá.

Ìṣe ikânu-ẹ̀ṣẹ

Olọrun mi, tọkàntọkàn li emi nkânu gbogbo ẹ̀ṣẹ mi ti mo fi bà Ọ ninu jẹ, nitoriti Iwọ mà dara jù nkan gbogbo lọ, ti Iwọ sì mà korira ẹ̀ṣẹ patapata; mo pinnu girigiri, nipa iranlọwọ ôre-ọfẹ rẹ, lati má tún bà Ọ ninu jẹ mọ ati lati ṣe ìṣẹ ẽtutu fun ẹ̀ṣẹ mi.

Ìṣe ifẹ́ni

Jesu, Olọrun mi, Iwọ ti o fẹran mi tobẹ ti Iwọ fi kú lori agbelebu nitori mi, ti Iwọ sì fi ara rẹ mimọ bọ ọkàn mi, mo fẹran rẹ tọkàntọkàn jù nkan gbogbo lọ; mo sì fẹ lati yè ati lati kú ninu ifẹ tirẹ. Jọwọ, wá gbé inu ọkàn mi, ti o n'ifẹ gidigidi lati dapọmọ Ọ.

AWỌN IṢE LEHIN KOMUNIONI

Iṣe iforibalẹ ati idupẹ

Olọrun mi, Jesu, mo fi tọkàntọkàn foribalẹ fun Ọ, mo sì dapọ mọ ibọ ti awọn Angẹli ati awọn Enia-Mimọ ìmâ fifun Ọ li ọrun rere. Bi emi kò ti lè dupẹ fun Ọ bi o ti yẹ nitori ôre nla rẹ, ti Iwọ ṣe fun mi, mo bẹ̀ wọn lati dupẹ lọwọ́ rẹ fun mi, ati lati yìn Ọ logo titilai nitori eyi.

Iṣe ifẹ̀ni ati ifitọrẹ

Olọrun mi Jesu, Iwọ ti iṣe inu rere pâpâ, mâ daná ifẹ̀ mimọ́ rẹ sinu ọkàn mi sibẹsibẹ. Fiyesi i lati gbà ifitọrẹ ti gbogbo ara mi ti mo ṣe fun Ọ, bi o tilẹ jẹpe ẹni alaiyẹ li emi nṣe, lati isisiyi lọ ki ohunkohun kì o máṣe lè yà mi kuro lọdọ rẹ mọ́.

Iṣe ibère

Olọrun mi Jesu, Iwọ ti o mọ̀ ailera ati ainí ọkàn mi, fun mi li ôre-ọfẹ lati ṣẹ atunṣe ìwa ibukùn mi, ki nsì lè lọ siwaju ninu iwa rere. Fiyesi i lati ràn Eklesia rẹ mimọ́ lọwọ́. Bukún fun awọn ôbí mi, olori, ọ̀rẹ́ ati ọ̀tá mi; ki o sì fun gbogbo wa li ôre-ọfẹ lati bá Ọ dapọṣọkan ni ijọ́ kan li ọrun rere. Amin.

AKIYESI

Bi misa, ti ise ebo majemu titun, t'o fi ola ati ogo fun Olorun julo, t'o si mu opo iranlowo ati itunu wá fun awon emi t'o wà l'ibi ina iwènumó, ati opo ôre-ofe fun awon onigbagbó t'o wà l'aiyé yi, lehinnâ a kò lè se isé t'o dara, t'o si n'itoye jù atigbó misa lo, t'o fi ijiyà ati ikú Oluwa wa Jesu-Kristi hàn wa l'ona alaita èje silè, t'o si ni ara ati èje Rè nitôto, labe aworan akara ati oti viní, sugbon lati gbó misa b'o ti ye, o tó k'a fi irò mimó mura si tele, k'a si fi iberu, sunmó altari lati fi ijosìn wa fun ola nla Olorun ati lati bère idarijì èse wa. L'akótan, o tó k'a fi ifiyesi ati tòwotòwo gbó misa.

ASPERGES ME

Antiphona. Orin isiwaju

Oluwa, Iwo yio fi ewé-hisopu bomiwón mi, ao si wè mi mó; Iwo yio wè mi, ao si so mi di funfun jù snò lo (omi didì t'o fún bi egbonowu, t'o subu lat'oke orun l'igba otutù).

Ps. Olorun, sànu funmi gegebi òpo ânu re.

Ogo ni fun Baba, ati fun Omo, ati fun Emi-Mimó. Bi o ti wà l'atetekose, bèni nisisiyi, bèni yio si mà ri nigbagbogbo, aiyé ainipekun. Amin.

L'ÌGBA PASKA (Ajinde Jesu-Kristi).

Antiphona. Orin iṣiwaju

Mo ti ri omi ti nṣàn lat'apá ọtún ile Ọlọrun wá alleluia : gbogbo awọn ẹnit'a fi omi yî wọ́n l'a sì gbà là, nwọn yio sì kọrin iyìn Ọlọrun, Alleluia, alleluia.

Ps. Ẹ ma yìn Oluwa, nitoriti O ṣeun, nitoriti ânu rẹ duro lailai.

Ogo ni fun Baba, ati fun Ọmọ ati fun Ẹmi-Mimọ́. Bi o ti wà l'atetekọṣe bẹ̀ni nisisiyi, bẹ̀ni yio sì ma ri nigbabgogbo aiye ainipẹkun. Amin.

S. Oluwa, fi ânu rẹ hàn wa.

M. K'o sì fun wa ni igbalà rẹ.

S. Oluwa gbọ́ adura mi.

Id. K'o sì jẹ ki ikigbe mi wá sọdọ rẹ.

S. Ki Oluwa wá pẹlu nyin.

Id. K'o sì wà pẹlu rẹ.

S. Ẹ jẹ k'a gbadura.

Oluwa Mimọ́. Baba Olodumare ati Ọlọrun aiyeraiye gbọ́ tiwa, k'o sì fiyesi lati ran Angẹli rẹ mimọ́ lat'ọrun wá, ki o lè dàbobo, ki o lè tìlẹhin, k'o lè bẹ̀wò, k'o sì lè gbija gbogbo awọn ẹnit'o pejọpọ̀ n'ile yi ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ADURA OJOJUMỌ TI MISA

Nigbati saserdoti duro l'ẹsẹ altari, o kà adura yi:

L'orukọ Baba, ati Ọmọ ati Ẹmi-Mimọ. Amin.

S. Emi o lọ s'ibi altari Ọlọrun.

M. Sọdọ Ọlọrun, ẹniti'o kún ìgba-ewe mi fun ayọ. (Ps. 42).

S. Ṣe idajọ mi, Ọlọrun, kó sì yà ọ̀ran mi s'ọ̀tọ kuro ninu ti orilẹ ède alaimọ. Gbà mi lọwọ alaisodo ati ẹlẹtàn.

M. Nitori Iwọ ni agbara mi, Ọlọrun; ẽṣe ti Iwọ fi ṣa mi tì? Ẹṣe ti emi fi nrin ninu ibanujẹ, niwọnigbati ọtá ni npọn mi l'oju?

S. Rán imọlẹ ati otitọ rẹ jade, awọn nâ l'o ṣe amọna mi, ti nwọn sì mu mi wá sori oke rẹ mimọ, ati sinu agọ rẹ.

M. Emi o lọ sibi altari Ọlọrun; sọdọ Ọlọrun. ẹniti'o kún ìgba-ewe mi fun ayọ.

S. Lara duru li emi o mâ yìn Ọ, Ọlọrun, Ọlọrun mi. Ẹṣe ti iwọ fi banujẹ? iwọ ọkàn ẽṣe ti iwọ fi yọ mi lẹnu.

M. Gbẹkẹle Ọlọrun, nitori emi o mâ yìn I sibẹsibẹ; On ni igbalà oju mi ati Ọlọrun mi.

S. Ogo ni fun Baba, ati fun Ọmọ, ati fun Ẹmi-Mimọ.

M. Bi o ti wà l'atetekọṣe, bẹ̀ni nisisiyi, bẹ̀ni yio sì mâ ri nigbagbogbo, aiyé ainipẹkun. Amin.

S. Emi o lọ sibi Altari Ọlọrun.

M. Sọdọ Ọlọrun, ẹniti'o kún ìgba-ewe mi fun ayọ.

S. Iranlọwọ wa mbẹ l'orukọ Oluwa.

M. Enit'o dá ọrun on aiyé.

S. Mo jẹwọ fun Ọlọrun Olodumare, etc.

M. Ki Ọlọrun Olodumare k'o ṣãnu fun ọ, k'o dari èṣẹ rẹ jì ọ, k'o sì mu de ibi iyè ainipẹkún

S. Amin.

M. Mo jẹwọ fun Ọlọrun Olodumare fun Maria alabukún, etc.

S. Ki Ọlọrun Olodumare k'o ṣãnu fun nyin, k'o dari èṣẹ nyin jì nyin, k'o sì mu nyin de ibi iyè ainipẹkún.

M. Amin.

S. K'Oluwa Olodumare at'alànu, k'o fun wa n'idarijì, ifijì at'imukuro èṣẹ wa.

M. Amin.

S. Ọlọrun b'Iwọ ba yípada si wa, Iwọ o tun só wa di alãye.

M. Awọn enia rẹ yio sì yọ ninu rẹ.

S. K'Oluwa fi ãnu rẹ hàn fun wa.

M. K'o sì fun wa n'igbala rẹ.

S. Oluwa, gbọ́ adura wa.

M. K'o sì jẹ k'igbe mi wá sọdọ rẹ.

S. K'Oluwa wà pẹlu nyin.

M. K'o sì wà pẹlu ẹmi rẹ.

Nigbati saserdoti lọ s'ori altari o wipe: Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, k'o pa èṣẹ wa rẹ́, k'awa lè yẹ lati ti ọkàn mimọ́ wọ inu ibi mimọ́ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Nigbati saserdoti f'ẹnuko altari o wipe: Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, nipa itoye awọn enia mimọ́ rẹ, ti ẹta-okú wọn wà nibi, ati nipa itoye ti gbogbo awọn enia mimọ́ iyokù, k'o lè wù Ọ lati dari gbogbo èṣẹ mi jì mi. Amin.

IPILẸṢẸ TI MISA

Ibukún ni fun Ọlọrun, Ẹni-Mẹtalọkan Mimọ́, ati fun iṣokán ailèpin. Ẹ jẹ k'a kọrin iyìn fun U, nitoriti O ṣãnu fun wa.

(Ps. 8). Oluwa, Oluwa wa, bi orukọrẹ ti ni iyìn to ni gbogbo aiyé!

Ogo ni fun Baba, ẹnit'o dá wa,

Ogo ni fun Ọmọ, ẹnit'o rà wa pada,

Ogo ni fun Ẹmi-Mimọ́, ẹnit'o sọ wa di mimọ́. Ibukún ni fun Ọlọrun, etc. *Titi de*, Ps.

(*L'ọjọ ọdún Enia-Mimọ́ kan a lè kà adura yi*).

Olododo yio gbà bi igi ọpẹ, yio sì bí si i bi igi opépe Libanoni; ao gbìn i n'ile Oluwa, ni agbalà ile Ọlọrun wa.

Ps. Ohun rere ni lati mà fi iyìn fun Oluwa; ati lati kọrin si orukọ rẹ, iwọ Ọga-Ogo.

Ogo ni fun Baba ati fun Ọmọ, ati fun Ẹmí-Mimọ́. Bi o ti wà l'àtetekọṣe, bẹ̀ni nisisiyi, bẹ̀ni yio sì mà ri nigbagbogbo, aiyé ainipẹkun. Amin.

Kyrie Eleison

Oluwa, ṣãnu fun wa (nigba mẹta).
Kristi, sãnu fun wa *(ter)*.
Oluwa, sãnu fun wa *(ter)*.

GLORIA IN EXCELSIS DEO

A kò kà adua yi l'igba àwẹ ati adfenti, ati ninu misa fun awọn okú

Ogo ni fun Ọlọrun l'oke ọrun ati l'aiye yi, alafia fun awọn enia t'o n'ilẹ inu rere. Awa nyìn Ọ, awa nfi ibukún fun Ọ, awa nforibalẹ fun Ọ awa nyìn Ọ logo, awa ndupẹ fun Ọ nitori ogo nla rẹ, Oluwa Ọlọrun, Ọba ọrun, Ọlọrun Baba Olodumare, Oluwa Jesu-Kristi, Ọmọ bibi ni kanṣoṣo; Oluwa Ọlọrun, ọdọ-agutan Ọlọrun, ọmọ ti Baba, Iwọ ẹnit'o kó ẹṣẹ aiye lọ, sânu fun wa, Iwọ ẹnit'o kó ẹṣẹ aiye lọ, gbà adura wa. Iwọ t'o joko l'ọwọ ọtún Baba, ṣânu fun wa Nitori Iwọ nikan ni mimọ, Iwọ nikan li Oluwa, Iwọ nikan Jesu-Kristi, pẹlu Ẹmi-Mimọ l'oga julọ ninu ogo Ọlọrun Baba. Amin.

Saserdoti yi pada si enia, o si wi pe:

S. Ki Oluwa wà pẹlu nyin.
In. Ki o si wà pẹlu ẹmi rẹ.

Adura

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, k'o dàbobo wa ninu gbogbo ewu t'ọkàn ati t'ara, ati nipa ẹbẹ Maria alabukún ati ologo, lailai wundia, iyá Ọlọrun; ti Josefu mimọ, ti awọn apostoli mimọ, Pitẹru on Paulu, ati ti gbogbo awọn Enia mimọ rẹ, l'ojurere ânu rẹ, k'o fun wa ni ilera

ati alafia, ki Eklesia rẹ ni ṣiṣẹgun lori gbogbo awọn ipọnju ati ẹkọkẹkọ, ki o lè ma fi ọkàn irọrun mimọ ati idakẹjẹ sìn Ọ; nipasẹ J.-K. Oluwa wa Amin.

Adura ekeji

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, nipa Ẹmi ẹnit'a nsọ gbogbo ajọ Eklesia dì mimọ, ti a sì nṣe akoso rẹ, gbà ẹbẹ t'awa nran siwaju rẹ fun gbogbo awọn onirùru oloyè mimọ ninu rẹ, pe nipa iranlọwọ ôre-ọfẹ rẹ, ki nwọn lè ma sìn Ọ nitôtọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa, Ọmọ rẹ t'o wà, t'o sì jba pẹlu rẹ, ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun Amin.

EPISTOLI

O yatọ fun ọdún mimọ ati ijọ ọsẹ.

Ikawe epistoli ti Paulu mimọ si awọn ará Filipi, IV, 4.

Ẹnyin olufẹ, ẹ ma yọ ninu Oluwa nigbagbogbo, mo tún wipe: ẹ ma yọ. Ẹ jẹ ki ìwa pẹlẹ nyin di mimọ fun gbogbo enia: Oluwa kùn si dẹdẹ. Ẹ maṣe darò ohunkohun; ṣugbọn nipa adura ati ẹbẹ pẹlu idupẹ, ẹ mâ fi ibère nyin hàn fun Oluwa li ohun gbogbo. Ki alafia Ọlọrun, t'o jù imọran gbogbo lọ, k'o sì pa nyin àiya ati ọkàn mọ ninu Kristi-Jesu. Lakotan, arakọnri, ohunkohun ti iṣe otitọ, ohunkohun ti iṣe ọwọ, ohunkohun ti iṣe ododo,

ohunkohun ti iṣe mimọ. ohunkohun ti iṣe fifẹ, ohunkohun t'o l'orukọ rere, ohunkohun t'o lè fà mi sinu ìwa rere, ohunkohun ti a lè yìn nimu iṣe enia, ẹ mâ gbà nkan wọnyi rò. Nkan wonyi ti ẹnyin ti kọ, ti ẹnyin sì ti gbà, ti ẹnyin sì ti gbọ, ti ẹnyin sì ti ri lọwọ mi, ẹ mâ ṣe wọn ; Ọlọrun alafia yio sì mâ wà pẹlu nyin.

Id Ọpẹ fun Ọlọrun.

Graduali.

Iwọ mâ ṣe Ọlọrun alâbo fun mi ati ile asálà lati gbà mi là. Ọlọrun, Iwọ ni mo gbẹkẹle ; Oluwa, lai máṣe jẹ ki oju ti mi. Oluwa, máṣe hùwa si wa gẹgẹbi ẹṣẹ wa, bẹni máṣe san a fun wa gẹgẹ bi aiṣedede wa. Ran wa l'ọwọ, Ọlọrun Ọlugbala wa, ati nitori ogo orukọ rẹ, Oluwa, k'O gbà wa silẹ, k'o sì dari ẹṣẹ wa jì wa nitori orukọ rẹ.

Ki saserdoti tó kà ihin rere o wipe :

Wẹ ọkàn mi ati ète mi mọ, Ọlọrun Olodumare, Iwọ t'o fi oguna wẹ ète Woli Isaia mọ ; l'ojurere ânu rẹ, k'o lè wù Ọ, lati wẹ mi mọ tobẹ ti mo lè wâsu ihin rere rẹ mimọ b'o ti yẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Oluwa, ki o lè wù Ọ lati bukún fun mi. Ki Oluwa wà ninu ọkàn mi ati ète mi k'emi lè wâsu ihin rere rẹ mimọ b'o ti yẹ. Amin.

EVANGẸLI

S. Ki Oluwa wà pẹlu nyin.
Id. Ki O sì wà pẹlu ẹmi rẹ.

S. Ipilęsę (tabi) itęle ihin rere mimọ, nipa ti Joanni, XIV, 15.

Id. Ogo ni fun Ọ, Oluwa.

Bi ẹnyin ba fẹ mi, ẹ pa ofin mi mọ, Emi o si bère lọwọ Baba, On yio si fun nyin li Olutunu omiran, ki o le mà bá nyin gbé titi lailai, Ẹmi otitọ ni, ẹniti araiyé kò lè gbà; nitoriti kò ri I, bẹni kò si mọ Ọ: ṣugbọn ẹnyin o mọ Ọ; nitoriti on yio bá nyin gbé, on yio si mà wà ninu nyin. Emi ki o fi nyin silẹ li alaini Baba: Emi yio tọ nyin wá. Niwọn igba diẹ, aiye kì o si ri mi mọ; ṣugbon ẹnyin o ri mi, nitoriti mo wà láye, ẹnyin o si wà láye pẹlu. Li ọjọ nà li ẹnyin o mọ pe emi wà ninu Baba mi, ati ẹnyin ninu mi, ati emi ninu nyin. Ẹniti o ba li ofin mi, ti o ba si pa wọn mọ, on nà li eniti o fẹ mi. Eniti o ba si fẹ mi, a o fẹ ẹ lati ọdọ Baba mi wá: emi yio si fẹ ẹ, emi yio si fi ara mi hàn fun u.

Id. Iyìn ni fun Ọ, Kristi.

Lęhinnà saserdoti f'ẹnuko ihin rere o si wipe: Nipa ọrọ ti ihin rere k'a lè pa ẹṣẹ wa rẹ.

CREDO IN UNUM DEUM

Mo gbà Ọlọrun kan, Baba Olodumare gbọ, ẹlẹda ọrun on aiye, ati ohun gbogbo ti a nri ati eyiti a kò ri. Mo si gbà Oluwa kan gbọ, Jesu-Kristi, Ọmọ bibi nikanṣoṣo ti Ọlọrun, ti a bi lat'odọ Baba ṣiwaju aiye gbogbo, Ọlọrun lat'inu Ọlọrun, imọlẹ lat'inu imọlẹ, Ọlọrun tòtọ lat'inu Ọlọrun tòtọ: Eniti a bí, ti a kò dá, Eniti o niwa kannà pẹlu Baba, lat'ọwọ Eniti a

ti dá olúun gbogbo. Ẹnit'o ti ọrun sọkalẹ wá ilẹ nitori awa enia ati nitori igbala wa; ẹnit'o sì gbà ẹran ara ninu Maria Wundia, nipa Ẹmi-Mimọ, t'o sì di enia. A sì kàn A mọ agbelebu pẹlu nitori wa. O jiyà lọwọ Pontiu-Pilatu, a sì sìn I: I'ijọ kẹta O tún jinde gẹgẹbi ọrọ Ọlọrun; O sì rè oke ọrun, O sì joko lọwọ ọtún Baba; Yio sì tún pada wá, ti on ti ogo, lati bá âye on okú wijọ; ijọba ẹniti kì yio ni ipẹkun. Mo sì gbà Ẹmi-Mimọ gbọ, Oluwa ati Olufuni ni iye, enit'o ti ọdọ Baba ati Ọmọ jade wá, pẹlu Baba ati Ọmọ ẹnit'a njumọ foribalẹ fun ti a sì nyìn logo; ẹnit'o; t'enu awọn Woli sọrọ. Mo sì gbà Eklesia (ijọ enia) ti njẹ ọkan, mimọ, katolika ati apostolika gbọ. Mo jẹwọ Ibatisi kan fun imukuro ẹṣẹ, emi sì nreti ajinde okú ati iye aiye ti mbọ wá. Amin.

S. Ki Oluwa wà pẹlu nyin.
Id. Ki o sì wà pẹlu ẹmí rẹ.

OFFERTORY

Emi o gbé Ọ ga, Oluwa, nitoriti Iwọ ti gbé mi dide. t'Iwọ kò sì jẹ ki awọn ọtá mi yọ mi. Oluwa Ọlọrun mi, emi ti kigbe pè Ọ, Iwọ sì ti mu mi lara da.

Angẹli Oluwa o yí awọn ẹnit'o bẹru Rẹ ká, yio sì gbà wọn silẹ. Ẹ tọ Ọ wò, ki ẹnyin sì ri pe olinurere ni Oluwa.

Ifitorẹ ti Hostia.

Baba mimọ́, Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, gbà ẹbọ alailabawọ́n yi ti emi iransẹ rẹ alaiyẹ rù si Ọ, Olọrun mî alâye ati tôtọ́, fun èṣẹ, ibi ati ijafara mi alainiye, ati fun gbogbo ẹnit'o wà nihin nisisiyi, bẹgẹgẹ pẹlu fun awọn onigbagbọ́ t'aiye t'okú; je k'o ṣe anfani fun igbalà mi ati tiwọn lati de ibi iye ainipẹkun. Amin.

Nigbati saserdoti fi ọti vini ati omi s'inu kalisi, o ma kà adura yi.

Olọrun, nipa isẹ iyanu Iwọ t'o dá enia l'iwa t'o l'ọlá tò bayi, t'o si ti tún u ṣe l'ọ́na t'o yà ni lẹnu jù bẹ́ lọ, tifun ni, nipa ọ̀rọ ijinlẹ ti omi ati ọti vini yi, k'a lè so wa di alabapin ninu Iwa-Olọrun rẹ, ẹniti o wù lati di alabapin ninu Iwa-enia wa, Jesu-Kristi Ọmọ rẹ, Oluwa wa, ẹnit'o wà, t'o si jọba pẹlu rẹ ninu isọkan ti Emi-Mimọ́, Olọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

Ifitorẹ ti kalisi

A rù kalisi igbalà si Ọ, Oluwa a si mbẹbẹ lodọ ânu rẹ, ki o lè goke lọ siwaju Olá nla rẹ mimọ́ bi ôrun didùn fun igbalà aratikalawa, ati fun ti gbogbo araiye. Amin.

Pẹlu irẹlẹ ati ibanujẹ okàn l'awa farahàn niwaju rẹ; Oluwa, gbà wa, k'o si je ki ẹbọ ti a rù si Ọ loni, k'o lè mâ wù Ọ, Oluwa Olọrun wa.

Wá, Olusọni dì mimọ́, Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, k'o si bukún fun ọgo oruko rẹ mimọ́.

L'ọjọ́ ọdún mimọ́ saserdoti kà adura yi nigbati'o bukún fun turari.

Nipa ẹbẹ Mikaẹli alabukún, olori awọn angẹli, t'o duro lapa ọtún ti altari turari, ati nipa ti gbogbo awọn ayanfẹ rẹ, ki o lè wù Oluwa lati bukún fun turari yi, ati lati gbà a bi ôrun didùn ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Nigbati saserdoti jó turari l'ori altari, o wipe : Ki turari yi ti Iwọ bukúnfun, Oluwa, ki o lè goke lọ siwaju rẹ, ki o sì lè mu ânu rẹ sokalẹ wá sori wa.

Oluwa, jẹ ki adura mi goke lọ siwaju rẹ bi turari, ki igbe ọwọ́ mi soke, k'o sì ri bi ẹbọ aṣálẹ.

Oluwa, fi ẹṣọ́ siwaju ẹnu mi, ati ilẹkun si ète mi, lati pa wọn mọ́, ki a máse fà ọkàn mi sinu ọ̀rọ buburu lati ṣe awawi fun ẹṣẹ mi.

Nigbati a jó turari niwaju saserdoti o wi pe : Ki Oluwa lè daná ifẹ rẹ ati ifẹni rẹ gbigbona ti kò nipẹkun sinu wa. Amin.

LAVABO

Nigbati saserdoti wẹ ọwọ́ rẹ, o kà adura yi.
Ps. 25.

Emi o wẹ ọwọ́ mi pẹlu awọn olododo, emi sì duro yí altari rẹ ká, Oluwa, k'emi lè gbọ́ ohùn iyìn rẹ, k'emi sì lè mâ rohìn gbogbo iṣẹ iyanu rẹ. Oluwa, emi ti fẹ ẹwà ile rẹ ati ibi ti Ọlá nla rẹ gbé wà. Máṣe jẹ ki ọkàn mi ṣegbé pẹlu awọn ẹlẹṣẹ, tabi ẹmi mi pẹlu awọn ẹni-

ẹje ; li ọwọ́ ẹniti iṣe aiṣododo wà, ọwọ́ ọtún wọn si kún fun ẹbun ; ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, emi ti nrin ninu ìwa ailẹṣẹ mi. Ẹṣẹ mi ti duro ṣinṣin ọ̀na otitọ. Ninu awọn ijọ enia l'emi o fi ibukún fun Ọ, Oluwa.

Ogo ni fun Baba, etc.

Suscipe, Sancta Trinitas

Olọrun Ẹni Mẹtalọkan Mimọ́, gbà ẹbọ yi ti a rù si Ọ l'iranti ti iyiya, ti ajinde ati ti igoke rè ọrun ti Oluwa wa Jesu-Kristi, ati ni ọlá ti Maria alabukún, lailai Wundia, ti Joanni Batisti alabukún, ti awọn apostoli mimọ́, Pitẹru on Paulu, ti awọn ẹniti a nṣe iranti wọn loni, ati ti gbogbo awọn enia mimọ́ iyokù ; jẹ k'o lè ṣe anfani fun ọlá wọn ati fun igbala wa, kio si lè wù awọn ẹniti a nṣe ọdún iranti wọn l'aiye yi, lati ṣipẹ fun wa l'ọrun rere ; nipasẹ Jesu-Kristi kanna Oluwa wa. Amin.

Orate fratres

Nigbati saserdoti yipada si awọn onigbagbọ́, o wi fun wọn pe :

S. Ẹnyin olufẹ. ẹ gbadua, ki ẹbọ mi ati ti nyin lè jẹ atewọ́gbà fun Olọrun, Baba Olodumare.

D. Ki Oluwa gbà ẹbọ nâ lọwọ́ rẹ fun ọlá ati ogo orukọ rẹ, fun anfani aratikalawa ati fun ti gbogbo ijọ enia rẹ mimọ́.

S. Amin.

Adura

Oluwa, ti ànu gbọ́ adura wa, K'o sì ti ojurere gbà ẹbọ ti awa iranṣẹ rẹ rù si Ọ, pe bi a ti rù u si ọlá orukọ rẹ k'o lè di ọ̀na fun wa lati rì ôre-ọfẹ rẹ gbà l'aiye yi, ati ìye ti kò nipẹkun laiye ti mbọ̀; nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

L'ojọ́ enia mimọ́ kan.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ k'o sọ ẹbun yi di mimọ́ t'a rù si Ọ l'ojọ ọdún oni yi ti Enia mimọ́ N. ọmọ-ọdọ rẹ, nipa ôre-ọfẹ rẹ k'o sì mu wá l'agbara to bẹ́ ti ninu asiki ati ipọnju k'a lè tọ́ ipa ọ̀na wá si ọlá rẹ; nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi, Ẹnit'o wà, t'o sì jọba pẹlu Rẹ, ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ́, Ọlọrun kan. Amin.

PREFACE

S. Aiye ainipẹkun.
Id. Amin
S. Ki Oluwa wà pẹlu nyin.
Id. Ki O sì wà pẹlu ẹmi rẹ.
S. Ẹ gbé ọkàn nyin soke.
Id. Awa gbé wọn soke si Oluwa.
S. Ẹ jẹ k'a dupẹ fun Oluwa Ọlọrun wa.
Id. Ó yẹ, o sì tọ́ k'a mà ṣe bẹ̀.

Adura t'o tẹle yi ni a mâ kà lojojumọ, bikọṣe l'ijọ́ ọṣẹ ati l'ijọ́ ọdún pataki.

O yẹ jojọ, o sì tọ́, iṣẹ isin wa ni, o si l'an-

fani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo, Oluwa mimọ́, Baba Olodumare, Ọlọrun aiyeraiye, nipasẹ Kristi Oluwa wa, nipa Ẹniti awọn Angẹli mà yìn Ọlá nla rẹ, awọn Alakoso mà foribalẹ fun U, awọn Alagbara mà wariri niwaju rẹ, awọn Ọrun ati awọn Agbara ọrun, ati awọn Serafimu mimọ́ mà jumọ́ ti orin ayọ̀ yìn I logo ; pẹlu gbogboawọn ẹmi ọrun wọnnyi, a bẹ Ọ, jẹ k'a dà ohùn wa pọ̀ṣọkan, k'a sì ti irẹlẹ wí pẹlu wọn pe

SANCTUS

Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́ l'Iwọ, Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun. Ọrun on aiye kún fun ogo rẹ. Ogo ni fun Ọ l'oke ọrun. Ibukún ni fun Iwọ. Ẹnit'o mbọ̀ l'orukọ Oluwa. Ogo ni fun Ọ l'oke ọrun.

POPER PREFACES

Adura fun ọjọ́ ọ̀tọ

Li ọjọ́ odún ti Mọtalọkan mimọ́ ati ni gbogbo ijọ́ ọsẹ bikoṣe l'ijọ́ odún pataki

O yẹ jọjọ, o sì tọ́, iṣẹ isìn wa ni, o sì l'anfani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo, Oluwa mimọ́, Baba Olodumare, Ọlọrunaiyeraiye, Iwọ pẹlu Ọmọbibi rẹ nikanṣoṣo, ati Ẹmi-Mimọ́ ti iṣe Ọlọrun kan ati Oluwa kan, ki iṣe kiki Ẹnikan, ṣugbọn Ẹni Mẹta

ninu ìwa kannà. Nitori eyi ti Iwọ fihàn wa niti ogo rẹ, on nà l'awa gbagbọ́ pẹlu niti Ọmọ rẹ ati niti Ẹmi-Mimọ́, tobẹ gẹ nipa jijẹwọ́ ìwa Ọlọrun kan tòtọ́ ati aiyeraiye, a nforibalẹ fun ìyàtọ ninu awọn ẹni mẹta, fun isọkan ninu ìwa ati fun ìdogba ninu Ọlá nla ; Eyi ti awọn Angẹli ati olori awọn Angẹli, awọn Kerubimu ati Serafimu mà yìn, ti nwọn kò si dawọduro lati mà fi ohùn kan korin lojojumọ wi pe :

Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, etc.

Adura fun ọjọ́ Ibi ti Jesu-Kristi, titide ọjọ́ Ifarahàn rẹ fun awọn ọba mẹta, a si fun kà a l'ọjọ́ ọdún ti Ukaristi mimọ́.

O yẹ jojọ, o si tọ́, isẹ isìn wa ni, osi l'anfani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo, Oluwa mimọ́, Baba Olodumare ati Ọlọrun aiyeraiye, nitoriti, nipa ọ̀rọ ijinlẹ ti Isọ Ọrọ di enia, imọlẹ titún ti ogo rẹ ti hàn loju okàn wa, pe b'a ti mọ On nà ninu aworan t'a lè ri bi Ọlọrun wa, nipa rẹ k'a lè fà wa s'ifẹ ohun t'a kò lè ri. Nitorinà pẹlu awọn Angẹli ati olori awọn Angẹli, pẹlu awọn Itẹ ati awọn Alakoso ati pẹlu awọn Ọmọ-ogun ọrun l'awa nkorin iyìn fun Ọ, t'a si nwi laisimi pe :

Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́ etc.

Adura fun ọjọ́ ifihàn ti Jesu-Kristi fun awọn ọba mẹta, t'a si kà l'ijọ́ meje lehin rẹ.

Oyẹ jojọ, o si tọ́, isẹ isìn wa ni, o si l'anfani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo Oluwa mimọ́ Baba Olodumare, Ọlọrun

aiyeraiye, nitori ti ọmọ bibi rẹ nikanṣoṣo, nigbat'o ti farahàn wa ninu ara ikú gẹgẹ bi tiwa, O tún sọ wa di alabapin ninu imọlẹ ti aikú rẹ nitori nà pẹlu awọn Angẹli ati olori awọn Angẹli, pẹlu awọn Itẹ ati awọn Alakoso, ati pẹlu gbogbo awọn Ọmọ ogun ọrun l'awa nkọrin iyìn fun Ọ, ti a sì nwí laisimi pe :

Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, etc.

Adura ti a kà l'ìgba àwẹ titilde ijọ ọsẹ ti Ijiyà ti Jesu-Kristi.

O ye jojọ, o sì tọ́, iṣẹ isìn wa ni, o sì l'anfani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo, Oluwa mimọ́. Baba Olodumare, Ọlọrun aiyeraiye, Iwọ ẹnit'o nlò àwẹ t'o npọ́n ara wa lọju lati fi tẹ́ ifẹkufẹ ara wa mọlẹ lati gbé ọkàn wa soke si Ọ, lati mu wa l'agbara ninu ikọ́lu èṣu, ati lẹhinnà lati san ẹsan ọrun fun wa, nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa, nipa ẹniti awọn Angẹli mà yìn Olá nla rẹ, awọn Alakoso mà foribalẹ fun U, awọn Alagbara mà wariri niwaju rẹ, awọn Ọrun ati awọn Ọmọ-ogun ọrun, ati awọn Serafimu mimọ́ mà jumọ́ fi orin ayọ̀ yin I l'ogo pẹlu wọn, a bẹ Ọ je k'a da ohùn wa pọ̀ ṣọ̀kan, k'a sì firẹlẹ wí pẹlu wọn pe : Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, etc.

Adura t'a kà l'ijọ ọsẹ ti ijiya Jesu-Kristi titi de ijọ karun t'ọsẹ mimọ́, ati l'ijọ ọdún ti agbelebu mimọ́.

O ye jojọ, o sì tọ́, iṣẹ isìn wa ni, o sì l'anfani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbagbo ati niba-

gbogbo, Oluwa mimó, Baba Olodumare, Olorun aiyeraiye, Iwọ ẹnit'o fi igbalà araiye mọ igi agbelebu, k'eyi t'o mu ikú wá fun wa, tún lè dì orisun titun, k'èṣu t'o ti lo igi lati fi tàn enia jẹ ati lati tẹ ẹ lori ba, ki a sì lè fi igi tẹ ẹ lori ba pẹlu, nipase Jesu-Kristi Oluwa wa, Ẹnit'awọn Angẹli mâ yìn ọlá nla rẹ awọn Alakoso mâ foribalẹ fun U, awọn Alagbara mâ wariri niwaju rẹ, awọn Ọrun ati awọn Serafimu mimó mâ jumó fi orin ayọ yin I logo; pẹlu wọn, a bẹ Ọ, jẹ k'a dà ohùn wa pọṣọkan, k'a sì fi irẹlẹ wí pẹlu wọn pe :

Mimọ, Mimọ, Mimọ, etc.

Adura ti a kà l'ojó Ajinde ti Jesu-Kristi ati ni ijó meje lehin rẹ.

O ye jojo, o sì tó, isẹ isìn wa ni, o sì l'anfani k'awa mâ yìn Ọ, Oluwa, logo nigbagbogbo, ṣugbọn jù gbogbo rẹ lọ nipataki l'ojó oni yi tabi l'akoko mimó yi ti a pa Kristi, ọdọ-agutan Paska wa, fi rùbọ; nitori On nâ ni ọdọ-agutan tòtó, t'o ti kó èṣẹ aiye lọ, nipa ikú rẹ ẹnit'o sì ti pa ikú wa rùn, ati nipa ajinde rẹ Ó tún ṣọ wa dì alâye. Nitorinâ pẹlu awọn Angẹli ati olori awọn Angẹli pẹlu awọn Itẹ ati awọn Alakoso ati pẹlu gbogbo awọn Ọmọ-ogun ọrun l'awa nkọrin iyìn fun Ọ t'a sì nwí l'aisimi pe :

Mimọ, Mimọ, Mimọ, etc.

Adura t'a nkà l'ojó igoke rẹ ọrun ti Jesu-Kristi, titi de ojó isọkalẹ ti Ẹmi Mimọ s'ori awọn apostoli.

O ye jojo, o sì tó, isẹ isìn wa ni, o sì l'anfani

k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo Oluwa mimọ́, Baba Olodumare, Ọlọrun aiyeraiye, nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa, lẹhin ajinde rẹ̀ Ẹnit'o ti ara rẹ̀ hàn fun gbogbo awọn ọmọ ẹhin rẹ̀ nigbangba, t'O si goke rẹ̀ orun l'oju wọn lati so wa di alapin ninu Iwa Ọlọrun rẹ̀. Nitorinà pẹlu awọn Angẹli ati olori awọn Angẹli pẹlu awọn Itẹ́ ati awọn Alakoso, ati pẹlu gbogbo awọn Ọmọ-ogun orun l'awa nkọrin iyìn fun Ọ, ti a si nwi laisimi pe : Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, etc.

Adura ti a kà n'ijọ́ satiday t'o ṣaju Isọkalẹ ti Ẹmi-Mimọ́, ati ni ijọ́ mefa lẹhin rẹ̀, ati ni misa ti Ẹmi-Mimọ́.

O ye jọjọ, o si tọ́, iṣẹ isìn wa ni, o si l'anfani, k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibigbogbo, Oluwa mimọ́, Baba Olodumare, Ọlọrun aiyeraiye ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa, lẹhin igbati o ti lọ soke gbogbo awọn orun, ti O si ti joko l'owọ́ otún rẹ̀, ẹnit'o tú Ẹmi-Mimọ́, ti O ti ṣe ileri jade sori awọn ọmọ ti O ti sọ d'ọmọ rẹ̀. Eyi nà l'o kún gbogbo awọn ẹnit'ọ wà lori gbogbo ilẹ aiye yi fun ayọ̀ nla ; niwọn igbati awọn Agbara orun ati awọn Angẹli alagbara nkọrin iyìn fun ogo rẹ̀, ti nwọn si nwi laisimi pe :
Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, etc.

Adura ti a nkà l'ọjọ ọdun Maria Mimọ́.

O ye jọjọ, o si tọ́, iṣẹ isìn wa ni, o si l'anfani k'awa mà dupẹ fun Ọ nigbagbogbo ati nibi-

gbogbo, Oluwa mimọ́, Baba Olodumare, Ọlọrun aiyeraiye, ati nipataki k'a ma yin Ọ, k'a ma fi ibukún fun Ọ, nipa bibọla fun iranti Maria Wundia alabukún, ẹnit'o loyún ọmọ bibi rẹ nikanṣoṣo, nipa agbara Ẹmi-Mimọ́, ati laiba ogo ìwa wundia rẹ je, t'o si bí Imọlẹ aiyeraiye fun aiye, Jesu-Kristi Oluwa wa, nipa Ẹnit'awọn Angẹli ma yin ọlá nla rẹ, awọn Alakoso ma foribalẹ fun U, awọn Alagbara ma wà riri niwaju rẹ, awọn Ọrun on awọn Ọmọ-ogun ọrun, ati awọn Serafimu mimọ́, ma jumọ́ fi orin ayọ̀ yin I logo ; pẹlu wọn a bẹ Ọ, je k'a da ohùn wa pọ̀ṣọkan k'a sì wi pẹlu wọn pe : Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́, etc.

Adura ti a kà l'ọjọ odún awọn Apostoli mimọ́.

O ye jọjọ, o sì tọ́, iṣẹ isin wa ni, o sì l'anfani, k'awa ma fi irẹlẹ bẹbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, Oluṣọ́ wa aiyeraiye, k'Iwọ máse fi agbo rẹ silẹ ṣugbọn k'Iwọ fi âbo rẹ titilọ pa a mọ́, nipa ẹ̀bẹ awọn Apostoli rẹ mimọ́, k'a lè mâ ṣakoso rẹ̀ nigbagbogbo lat'ọwọ́ awọn amọ̀na kannà ti Iwọ fi ṣe oluṣọ́ rẹ bi awọn aròpo rẹ lati mâ ṣe iṣẹ ti Iwọ beresi titilọ. Nitorinà pẹlu awọn Angẹli ati olori awọn Angẹli, pẹlu awọn Ìtẹ́ ati awọn Alakoso,ati pẹlu gbogbo awọn Ọmọ-ogun ọrun l'awa nkọrin iyìn fun Ọ, ti a sì wi laisimi pe :

Mimọ́, Mimọ́, Mimọ́ l'Iwọ Oluwa, Ọlọrun awọn Ọmọ-ogun, ọrun ou aiye kún fun ogo rẹ. Ogo ni fun Ọ l'oke ọrun. Ibukún ni fun Iwọ ẹnit'o mbọ̀ l'orukọ Oluwa. Ogo ni fun Ọ l'oke ọrun.

CANON MISSAE

Te igitur, clementissime Pater, per Jesum Christum Filium tuum Dominum nostrum supplices rogamus ac petimus, uti accepta habeas, et benedicas, hæc+dona, hæc+munera, hæc+sancta sacrificia illibata, in primis quæ tibi offerimus pro Ecclesia tua sancta catholica : quam pacificare, custodire, adunare, et regere digneris toto orbe terrarum, una cum famulo tuo Papa nostro N. et Antistite nostro N. et omnibus orthodoxis, atque catholicæ et apostolicæ fidei cultoribus.

Commemoratio pro vivis.

Memento, Domine, famulorum famularumque tuarum N. et N. et omnium cir-

ILANA MISA

Nję, nitorinà awa nfi irẹlẹ bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, Baba alânu julọ nipa Jesu-Kristi Ọmọ rẹ, Oluwa wa, lati fi ọju rere gbà, ati lati bukúnfun awọn ẹbun yi, awọn ọrẹ yi, awọn ẹbọ mimọ́ ati alailabawọ́n yi ti awa ru si Ọ, nipataki fun Eklesia rẹ mimọ́ katọlika, ki o lè wù Ọ lati fun u l'alafia, lati dâbobo o, lati mu u duro ṣinṣin ninu iṣọkan, ati lati ṣe akoso rẹ̀ ni gbogbo ilẹ aiye : bẹgẹgẹ pelu iranṣẹ rẹ Papa wa N. Bisọpu wa N., ati gbogbo awọn onigbagbọ́ totọ́, t'o njẹwọ́ igbagbọ́ katọliki ati apostọliki.

Iranti fun awọn alàye.

Oluwa, ranti awọn ọmọ-ọdọ rẹ, t'okọnri t'obiri N. N., ati gbogbo awọn t'o wà ni-

cumstantium, quorum tibi fides cognita est, et nota devotio : pro quibus tibi offerimus, vel qui tibi offerunt hoc sacrificium laudis, pro se, suisque omnibus, pro redemptione animarum suarum, pro spe salutis et incolumitatis suæ ; tibique reddunt vota sua æterno Deo, vivo et vero.

Communicantes, et memoriam venerantes, in primis gloriosæ semper virginis Mariæ, genitricis Dei et Domini nostri Jesu-Christi : sed et beatorum Apostolorum ac Martyrum tuorum. Petri et Pauli, Andræ, Jacobi, Joannis, Thomæ, Jacobi, Philippi, Bartholomæi, Matthæi Simonis et Thaddæi : Lini, Cleti, Clementis. Xisti, Cornelii, Cypriani, Laurentii, Chrysogoni, Joannis, et Pauli, Cosmæ et Damiani, et omnium

hinyi nisisiyi t'igbagbó at'ifọkansin wọn di mimọ́ fun Ọ, ti awa sì ru ẹbọ iyìn yi si Ọ fun, tabi ti nwọn ru u si Ọ fun ara wọn, arále wọn ati awọn ọrẹ wọn, fun idándè ọkàn wọn, fun ireti igbalà ati ipamọ́ wọn, ti nwọn sì fi ẹbẹ wọn fun Ọ, Ọlọrun aiyeraiye, alâye ati tôtọ́.

Bi awa ti nṣe ajọpín ninu idapọ kannã, bi a sì ti nbọlafun iranti, nipataki ti Maria lailaí wundia ologo, Iyá Oluwa ati Ọlọrun wa Jesu-Kristi, ti awọn apostoli ati martiri rẹ, Piteru on Paulu, Anderu, Jakobu, Joanu, Tomasi, Jakobu, Filipi, Bartolomeu, Mateu, Simoni ati Tadeu, Lini, Kletu, Klementi, Sisti, Korneli, Sipriani, Lorensu, Krisogonu, Joanu on Paulu, Kosmu on Damianu, ati ti gbogbo awọn enia mimọ́ ; nipa itoye

sanctorum tuorum : quorum meritis precibusque concedas, ut in omnibus protectionis tuæ muniamur auxilio. Per eumdem Christum Dominum nostrum, Amen.

Hanc igitur oblationem servitutis nostræ, sed et cunctæ familiæ tuæ, quæsumus Domine, ut placatus accipias : diesque nostros in tua pace disponas, atque ab æterna damnatione nos eripi, et in electorum tuorum jubeas grege numerari. Per Christum Dominum nostrum. Amen.

Quam oblationem tu Deus in omnibus, quæsumus, bene + dictam, adscri+ptam, ra + tam, rationabilem, acceptabilemque facere digneris : ut nobis. Cor + pus. et San + guis fiat dilectissimi Filii tui Domini nostri Jesu-Christi.

ati adura awọn ẹni wọnyi ti fun wa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, k'awa lè ri iranlọwọ ábo rẹ gbà nigbagbogbo ninu ohun gbogbo ; Nipasẹ Jesu-Kristi kannâ, Oluwa wa. Amin.

Nje nitorinâ, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, k'o ti ojurere gbà ẹbọ yi ti isìn wa, ati ti gbogbo arále rẹ pẹlu ; k'o fun wa l'alafia rẹ niwọn ọjọ aiye wa, k'o sì jẹ k'a pa wa mọ kuro ninu egbé ainipẹkun, k'a sì gbà wa sinu agbo awọn ayanfẹ rẹ ; nitori Oluwa wa J.-K. Amin.

Awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, Ọlọrun, ki o lè wu Ọ lati bukúnfun ọrẹ-ẹbọ yi ninu ohun gbogbo, lati gbà a, lati fọhunsi i, lati sọ ọ di ẹlẹmi ati atẹwọgbà, ki o lè di ara on ẹjẹ ti Ọmọ rẹ olufẹ julọ, Oluwa wa J.-K. fun wa.

Qui pridie quam pateretur, accepit panem in sanctas ac venerabiles manus suas : et elevatis oculis in cœlum ad te Deum Patrem suum omnipotentem, tibi gratias agens, bene + dixit, fregit, deditque discipulis suis, dicens: Accipite. et manducate ex hoc omnes.

Hoc est enim Corpus meum

Simili modo postquam coenatum est, accipiens et hunc praeclarum Calicem in sanctas ac venerabiles manus suas : item tibi gratias agens, bene + dixit, deditque discipulis suis, dicens : Accipite et bibite ex eo omnes.

Hic est enim calix Sanguinis mei, novi et æterni testamenti : mysterium fidei : qui pro vobis et pro multis effundetur in remissionem peccatorum,

L'ojó t'o ṣaju ijiya rẹ, ẹni t'o mu akara l'ọwọ́ rẹ̀ mimọ́, t'o sì l'ọlá, nigbati o sì ti gb oju rẹ̀ soke ọrun sì Ọ, Olọrun Baba rẹ̀ Olodumare, ti o sì ti dupẹ lọwọ́ rẹ̀, O sure si i, O bu u, O sì fifun awọn ọmọ ẹhin rẹ̀, O wipe : Ẹ gba, ki gbogbo nyin sì jẹ ninu rẹ̀ :

Nitori eyiyi li ara mi

Bẹgẹgẹ lẹhin igbati o jẹun tán, O sì gbé kalisi iyebiye yi sì ọwọ́ rẹ̀ mimọ́, t'o sì l'ọlá, nigbati O sì ti dupẹ l'ọwọ́ rẹ̀, O sure si i, O sì fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, O nwipe. Ẹ gbà ki gbogbo nyin sì mu ninu rẹ̀ :

Nitori eyi ni kalisi ti ẹjẹ mi, ti majẹmu titun ati aiyeraiye, ọrọ ijinlẹ ti igbagbọ́, eyi t'ao ta silẹ fun nyin ati fun ọpọlọpọ enia fun imukuro ẹṣẹ.

Hæc quoties cumque feceritis in mei memoriam facietis.

Post consecrationem

Unde et memores, Domine, nos servi tui, sed et plebs tua sancta, ejusdem Christi Filii tui Domini nostri tam beatæ passionis, necnon et ab inferis resurrectionis, sed et in cœlos gloriosæ ascensionis : offerimus præclarœ Majestati tuæ de tuis donis ac datis, Hostiam + puram, hostiam + sanctam, hostiam + immaculatam, panem + sanctum vitæ æternæ, et calicem + salutis perpetuæ.

Nigbakugba tiẹnyin ba nṣe ohun wọnyi, ẹ mà ṣe wọn ni iranti mi

Lẹhin Isọdimimọ

Nitorinà awa iranṣẹ rẹ, Oluwa, ati pẹlu wa awọn enia rẹ mimọ, l'iranti ti ijiya t'o ni ibukún ti Kristi kannâ Ọmọ rẹ, Oluwa wa, ti ajinde rẹ kuro ninu okú, ati ti igoke rẹ orun rẹ, l'a rú ninu ẹbun ati ọrẹ rẹ hostia funfún, hostia mimọ, hostia alailabawọn, àkara mimọ ti iyè ainipekún, ati kalisi ti igbalà ainopin si Ọlánlánlá rẹ.

Supra quæ propitio ac sereno vultu respicere digneris : et accepto habere, dignatus es munera pueri tui justi Abel, et sacrificium patriarchæ nostri Abrahæ, et quod tibi obtulit summus sacerdos

Oluwa, ki o lè wù Ọ lati fi ânu ati oju rere wò awọn ọrẹ yi, ati lati tẹwọgbà wọn, gẹgẹ bi oti wù Ọ lati tẹwọgbà ọrẹ ti Abẹli, ọmọ-ọdọ rẹ olododo, ati ẹbọ ti Abrahamu, Baba nla wa, ati ẹbọ

tuus Melchisedech, sanctum sacrificium, immaculatam hostiam

Supplices te rogamus, omnipotens Deus: jube hæc perferri per manus sancti Angeli tui in sublime altare tuum. in conspectu divinæ Majestatis tuæ: ut quotquot, ex hâc altaris participatione, sacro sanctum Filii tui, Cor+pus, et San + guinem sumpserimus, omni benedictione cœlesti, et gratiâ repleamur., Per eumdem Christum Dominum nostrum. Amen.

Commemoratio pro Defunctis

Memento etiam Domine, famulorum famularumque tuarum N. et N. qui nos præcesserunt cum signo fidei, et dormiunt in somno pacis.

Ipsis Domine, et omnibus in Christo qui-

mimọ́ ati alaibawọn, ti Melkisedeki olori alufa rẹ ti rú si Ọ.

Awa nti irẹlẹ bẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ Ọlọrun Olodumare, k'o paṣẹ k'a mu ọrẹ wọnyi lọ sori altari rẹ loke ọrun niwaju Ọlá nlá rẹ mimọ́ lat'ọwọ́ Angeli rẹ mimọ́, ki gbogbo awa ti, nipa ṣiṣe alabapin ti altari yi, yio gbà ara on ẹjẹ mimọ́ julọ ti Ọmọ rẹ, k'a lè fi gbogbo ibukún ati ôre-ọfẹ ọrun kún wa; nitori J.-K. nâ, Oluwa wa. Amin.

Iranti awọn okú.

Oluwa, ranti pẹlu awọn ọmọ ọdọ rẹ, t'o kọnri t'obiri N. N., t'o lọ ṣiwaju wa pẹlu àmi igbagbọ́, t'o sì sùn orun alafia.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, k'o fun wọn

escentibus, locum refrigerii. lucis et pacis, ut indulgeas deprecamur. Per eumdem Christum Dominum nostrum. Amen.

Nobis quoque peccatoribus famulis tuis, de multitudine miserationum tuarum sperantibus, partem aliquam et societatem donare digneris cum tuis sanctis Apostolis et Martyríbus: cumJoanne, Stephano, Matthia, Barnaba, Ignatio, Alexandro, Marcelino, Petro, Felicitate,Perpetua,Agatha, Lucia, Agnete, Cœcilia, Anastasia, et omnibus sanctis tuis : intra quorum nos consortium, non aestimator meriti, sed veniæ, quæsumus, largitor admitte. Per Christum Dominum nostrum. Per quem haec omnia, Domine semper bona creas, sancti + ficas, vivi + ficas, bene + di-

ati gbogbo awọn ẹnit'o simi ninu Kristi l'ibi itura, imọlẹ ati alafia; nipasẹ J.-K. kannâ, Oluwa wa. Amin.

Ati fun awa ẹlẹṣẹ, iranṣẹ rẹ, t'o ngbẹkẹle ọ̀pọ ânu rẹ, ni k'o fiyesi i lati sọ di alajọpin ati ẹgbẹ pẹlu awọn apostoli rẹ mimọ́ ati martiri, pẹlu Joanu, Stefani, Mattia, Barnaba, Ignatio, Alesanderu, Marsellino, Piteru, Felisitati, Perpetua, Agata, Lusia, Agnesi, Sesilia, Anastasia, ati pẹlu gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ, sinu ẹgbẹ awọn ẹniwọnyi, a mbẹ̀ Ọ, ni k'o gbà wa, ki iṣe nipa wiwọn itoye wa wò, bikoṣepe nipa didari ẹ̀ṣẹ wa jì wa; nipasẹ J.-K. Oluwa wa, lat'ọwọ́ ẹniti, Oluwa, Iwọ ma da gbogbo ohun wọnyi nigbagbogbo, Iwọ sọ wọn dì mimọ́ ati alâye, Iwọ bukún-

cis, et præstas nobis. Per i + psum, et cum i + pso, et in i + pso est tibi Deo Patri + omnipotenti, in unitate spiritus + sancti omnis honor et gloria.

S. Per omnia sæcula sæculorum.
Id. Amen.
Oremus, Præceptis salutaribus moniti et divinâ institutione formati, audemus dicere:
Pater noster, etc.

Libera nos, quæsumus Domine, ab omnibus malis, præteritis, præsentibus et futuris : et intercedente beatâ et gloriosâ semper virgine Dei genitrice Maria, cum beatis apostolis tuis Petro et Paulo, atque Andreâ, et omnibus sanctis, da propitius pacem in diebus nostris : ut ope misericordiæ tuæ adjuti, et a peccato simus semper liberi, et ab fun wọn, Iwọ sì ti wọn fun wa. Nipa ẹni, ati ninu ẹniti gbogbo ọlá ati ogo ni fun Ọ, Baba Olodumare, ninu iṣọkan ti ẹni mimọ.

S. Aiye ainipẹkún.
Id. Amin.
K'a gbadua. Nipa ilana atewọgbà ti Jesu-Kristi ati nipa ẹkọ mimọ t'o ti kọ wa, awa nfi igboiya wipe :
Baba wa ti mbẹ l'ọrun, etc.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, gbà wa kuro ninu gbogbo tulasin t'o ti koja, t'isisiyi ati eyi ti mbọ wá : lojurere ânu rẹ k'O si fun wa l'alafia l'ijọ aiye wa, nipa ẹbẹ ti Maria alabukún ati ologo, lailai wundia, Iyá Olọrun, ,pẹlu ti awọn apostoli rẹ alabukún, Piteru on Paulu, ati Anderu, ati ti gbogbo awọn enia mimọ pe, nipa iranlọwọ ânu rẹ, k'a lè là

omni perturbatione securi. Per eumdem Dominum nostrum Jesum Christum Filium tuum. Qui tecum vivit et regnat in unitate spiritus sancti Deus Per omnia sœcula sœculorum. Amen.

S. Pax + Domini, sit + semper vobis + cum.

Id. Et cum spiritu tuo.

kuro ninu ẹṣẹ ati iberu gbogbo nigbagbogbo; nipasẹ Oluwa wa J.K. kannâ, Ọmọ rẹ, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Iwọ, ninu iṣọkan ti Ẹmi-mimọ Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

S. Ki alafia Oluwa k'o ma wà pẹlu nyin nigbagbogbo.

Id. K'o sì wà pẹlu ẹmi rẹ.

Hæc commixtio et consecratio Corporis et Sanguinis Domini nostri Jesu-Christi, fiat accipientibus nobis in vitam æternam. Amen.

Ki idapọ ati isọdimimọ yi ti ara ati ẹjẹ ti Oluwa wa Jesu-Kristi, ti a fẹ gbà, ki o lè mu wa de ibi iye ti kò nipẹkun. Amin.

Agnus Dei qui tollis peccata mundi, miserere nobis *(bis)*.

Agnus Dei qui tollis peccata mundi, dona nobis pacem.

Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'o kó ẹṣẹ aiye lọ, sànu fun wa *(bis)*.

Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'o kó ẹṣẹ aiye lọ, fi alafia fun wa.

Ninu misa fun awọn okú, a wipe :

Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ, fun wọn l'isimi *(bis)*.
Ọdọ-Agutan Ọlọrun t'o kó ẹ̀ṣẹ aiye lọ, fun wọn l'isimi ti kò nipẹkun.

Oluwa Jesu-Kristi Iwọ t'O wi fun awọn apostoli rẹ : alafia ni mo fi silẹ fun nyin, alafia mi ni mo fi fun nyin : má ṣe fiyesi ẹ̀ṣẹ mi bikoṣe igbagbọ́ Eklesia rẹ ; k'o sì fun u l'alafia ati iṣọkan nâ t'o wù ifẹ́ rẹ; Iwọ t'O jẹ Ọlọrun, t'O wà, t'O sì jọba lai ati lailai. Amin.

A kò kà adura yi ninu misa fun awọn okú.

Oluwa Jesu-Kristi Ọmọ Ọlọrun alâye, Iwọ Ẹni nipa ifẹ́ Baba ati ajumọṣe Emi-Mimọ́, t'o ti fun araiye l'iye nipa ikú rẹ, fi ara on ẹ̀jẹ rẹ mimọ́ julọ yi gbà mi kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ mi ati gbogbo awọn tulasin miran ; k'o sì mu ki emi mâ pa ofin rẹ mọ́ nigbagbogbo, lai má sì ṣe jẹ k'emi yàpa kuro lọdọ rẹ ; Iwọ t'O jẹ Ọlọrun, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Ọlọrun nâ Baba ati Ẹmi-Mimọ́, ainipẹkun. Amin.

Oluwa Jesu-Kristi, máṣe jẹ k'ibapin ninu ara rẹ, ti emi alaiyẹ fẹ́ gbà, pada di idajọ ati idalẹbi mi ; ṣugbọn nipa ânu rẹ, jẹ k'o di àbo ati ohun imularada ti ara ati ọkàn mi; Iwọ t'O jẹ Ọlọrun, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Ọlọrun Baba ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ́, aiye ainipẹkun. Amin.

Emi o mu akara ọrun, emi o sì mà kigbe pè orukọ Oluwa.

Ki saserdoti to gbà komunioni , o wi làrin mẹta pe :

Oluwa emi kò yẹ k'Iwọ wọ abẹ orule mi, ṣugbọn sọ kiki ọ̀rọ̀ nikan, a o sì mu ọkàn mi lara dá.

Ki ara Oluwa wa Jesu-Kristi pa ọkàn mi mọ́ titi iyè ti kò nipẹkun. Amin.

Saserdoti wi ki o to gbé kalisi si ọwọ́ rẹ̀ pe :

Kil'emi o fifun Oluwa nitori gbogbo ôre rẹ si mi? emi o mu kalisi igbalà, emi o sì mà kigbe pè orukọ Oluwa. Emi o kigbe pè Oluwa nipa fifi iyìn fun U, ao sì gbà mi l'ọwọ́ awọn ọtá mi. Ki èjẹ Oluwa wa Jesu-Kristi, pa ọkàn mi mọ́ titi iyè ti kò nipẹkun. Amin.

Nigbati saserdoti ti gbà komunioni tán o wipe :

Oluwa mu k'a pa mọ́ l'ọkàn funfun sakramenti yi t'a ti fi ẹnu wa gbà, ati ki ôre t'a ṣe fun wa n'igba aiye wa lè di ọ̀na igbalà ainipẹkun fun wa.

Oluwa, jẹ ki ara rẹ ti mo ti gbà ati èjẹ rẹ ti mo ti mu, lẹmọ́ inu mi, k'o sì fifun mi, ki abawọ́n èṣẹ kan máṣe tún duro ninu mi, ti a fi sakramenti alailèri ati mimọ́ bọ́; Iwọ t'O wà, t'O sì jọba, aiye ainipẹkun. Amin.

ADURA KOMUNIONI

Ohun kan li emi torọ lọdọ Oluwa. on nà li emi o mâ wá kiri : ki emi lè mâ gbé inu ile Oluwa ni gbogbo ọjọ aiye mi. Ẹ tọ Ọ wò, k'ẹ sì ri pe olinurere ni Oluwa ; alabukún fun ni ọkọnri nà t'o gbẹkẹle Ẹ.

L'ọjọ Enia mimọ kan

Alabukún fun ni ọmọ-ọdọ nà nigbati Oluwa rẹ ba de, ti yio bá a kì o mâ ṣ'ọna. Bi ẹnikan ba nfẹ lati tọ mi lẹhin, k'o sẹ ara rẹ, k'o sì gbé agbelebu rẹ, k'o sì mâ tọ mi lẹhin.

S. Ki Oluwa wà pẹlu nyin.
Id. Ki o sì wà pẹlu ẹmi rẹ.

ADURA LEHIN KOMUNIONI

Ẹ jẹ k'a gb'adura. Oluwa, da ẹnu ifẹ rẹ s'ori wa pe, nipa ânu rẹ, k'Iwọ lè sọ awọn ẹniti Iwọ fi onjẹ orun kannâ bọ, di ọkan, nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi, t'Ọ jẹ Ọlọrun, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Iwọ ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ. aiye ainipẹkun. Amin.

Bi awa ti gbà onjẹ orun ni ṣiṣe iranti Maria alabukún, lailai wundia, ati gbogbo awọn enia-mimọ rẹ, fifun ni Oluwa, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, ki eyi t'a bọla fun l'ìgba aiye wa, k'a lè ri gbà l'ibi ayọ ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

S. Ki Oluwa wà pẹlu nyin.
Id. K'o sì wà pẹlu ẹmí rẹ.
S. Ẹ lọ, a ti ṣe misa tán (tabi) jẹ k'a f'ibukún fun Oluwa.
Id. Ọpẹ ni fun Ọlọrun.

(Ninu misa fun awọn okú.)

S. Ki nwọn lè simi l'alafia
Id. Amin.

Ki saserdoti to bukún fun awọn onigbagbọ o wipe :

Ọlọrun Ẹni Mẹtalọkan mimọ, ti ojurere gbà ijọsìn mi, k'O sì tẹwọgbà ẹbọ ti emi alaiyẹ ti ru si Ọlá nla rẹ, ati nipa ânu rẹ, jẹ k'o lè jẹ ẹbọ ètutu fun ara mi ati fun gbogbo awọn ẹniti mo ti ru u fun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

S. Ki Ọlọrun Olodumare Baba, Ọmọ ati Ẹmi-Mimọ bukúnfun nyin.
Id. Amin.

S. *Ipilẹṣẹ Ihin rere mimọ nipa ti Johanu*
Id. Ogo ni fun Ọ, Oluwa.

Li àtetekọṣe li Ọrọ wà, Ọrọ sì wà pẹlu Ọlọrun, Ọlọrun sì li Ọrọ nâ. On nâ l'o sì wà l'àtetekọṣe pẹlu Ọlọrun. Lat'ọwọ rẹ li a ti dá ohun gbogbo ; lehin rẹ kò sì si ohun kan t'a dá ninu ohun t'a dá. Ninu rẹ ni iye wà; iye nâ sì ni imọlẹ araiye Imọlẹ nâ sì nmọlẹ ninu òkunkun ; òkunkun nâ kò si mọ Ọ. Ọkọnri kan wà t'a rán lat'ọdọ Ọlọrun wá, orukọ ẹniti ẹjẹ Jeanu. On nâ l'o wá lati jẹri, ki o lè ṣe ẹlẹri fun Imọlẹ nâ, ki

gbogbo enia k'o lè gbagbó nipasẹ rẹ. On kì iṣe Imọlẹ nâ, ṣugbọn on ni yio ṣe ẹlẹri fun Imọlẹ nà. Eyi l'Imọlẹ tôtọ ti nmọlẹ fun gbogbo enia t'o wá si aiye yi. On wá l'aiye, nipasẹ rẹ li a sì ti dá aiye, aiye kò sì mọ Ọ. O wá sinu ohun ini tirẹ awọn ará tirẹ kò sì gbà A. Ṣugbọn gbogbo awọn t'o gbà A li O fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, eyi ni awọn t'o gbà orukọ rẹ gbó. Awọn eniti'a bí, ki iṣe nipa ti ẹjẹ tabi nipa ti ifẹ ara, bẹni kì iṣe nipa ifẹ ti enia, bikoṣe nipa ti Ọlọrun. A sì ṣọ Ọrọ di ara, on sì mba wa gbé (awa sì ri ogo rẹ, ogo t'o dabi ti Ọmọ bibi kanṣoṣo ti Baba) t'o kún fun ôre-ọfẹ ati otitọ.

Id. Ọpẹ ni fun Ọlọrun.

ADURA MISA FUN AWỌN OKU

L'IJỌ ISÌNKU

Ant. Oluwa, fun awọn ẹmí l'isimi ainipẹkun, k'o sì fi imọlẹ ti kò nipẹkun hàn wọn. Ps. Ọlọrun, ni Sioni l'o yẹ k'a kọrin yìn Ọ, k'a sì sẹ ileri ifẹ fun Ọ ni Jerusalẹmu. Gbọ adura mi, si ọdọ rẹ ni gbogbo awọn enia yio mâ wá,

Adura

Ọlọrun, nipa ìwa rẹ Iwọ ẹniti'O mura nigbagbogbo lati mâ ṣânu ati lati mâ dariji, awa nfi irẹlẹ bẹbẹ lọdọ rẹ fun ẹmi ọmọ-ọdọ rẹ okọnri (tabi obirin) N., ẹniti Iwọ paṣẹ fun loni lati ṣi kuro ninu aiye yi.

K'Iwọ máṣe jẹ k'o ṣubu si ọwọ́ ọtá, k'a má sì ṣe gbagbé rẹ titilai, ṣugbọn k'o kuku paṣẹ fun awọn angẹli rẹ lati gbà a, ati gbé e lọ si ọrun rere, ilú rẹ ainipẹkun, pe bi on ti gbẹ́kẹle Ọ, bi on sì ti gbà Ọ gbọ́, ki o máṣe ri ijiyà ọrun-apàdi, bikoṣe ki o lè ri ayọ̀ ainipẹkun gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun baba tabi iyá

Ọlọrun, Iwọ ẹnit'O paṣẹ fun wa lati bọ̀wọ̀ fun baba on iyá wa, nipa ànu rẹ, k'o ṣànu fun ẹmí ti baba on iyá mi, k'O dari èṣẹ wọn jì wọn, k'o sì jẹ k'emi lè ri wọn n'ijọ́ kan. l'ibi ayọ̀ ogo ti kò nipẹkun. Nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ihawe Epistoli ti Apostoli Paulo mimọ́ si ará Tessalonika (1-4)

Ẹnyin arákọnrin, a kò fẹ ki ẹnyin k'o wà ninu aimọ̀, niti awọn t'o sùn, pe ki ẹnyin máṣe binujẹ, gẹgẹbi awọn ẹlomiran ti kò ni ireti. Nitori pe, bi awa ba gbagbọ́ pe Jesu ti kú, ati pe O sì tún jinde, bẹgẹgẹ pẹlu ni Ọlọrun yio mu awọn ẹnit'o sùn ninu Jesu wá pẹlu Rẹ̀. Nitori eyiyi l'awa wi fun nyin nipa ọ̀rọ Oluwa pe, awa t'o wà l'âye, t'a sì dasi titi d'igba wiwá Oluwa, awa ki yio ṣaju awọn t'o sùn. Nitori Oluwa tikalarẹ̀, li aṣẹ ati li ohùn olori awọn Angẹli, ati l'ipè Ọlọrun yio sọkalẹ l'at'ọrun wá; ati awọn t'o ti kú ninu Kristi ni yio tetekọ jinde. Nigbanâ li ao si gbé awa t'o wà l'âye, t'o sì kùn, lọ s'oke pẹlu nwọn sinu awọ-sama

lati pade Kristi l'ofurufu, bẹ̀ni awa o sì ma wà titi lai pẹlu Oluwa. Nitorinâ ẹ ma fi ọ̀rọ wonyi tù ara nyin ninu.

Graduali

Oluwa fun awọn ẹmi l'isimi ainipẹkun, k'o sì fi imọlẹ ti kò nipẹkun hàn wọn.

Ps. Olododo yio wà niranti titi lai. On kì yio bẹru ahọ́n buburu.

Oluwa tù awọn ẹmi ti gbogbo awọn onigbagbọ́ t'o ṣe alaisi kuro ninu gbogbo èwọn ẹṣẹ wọn, ati nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ, jẹ ki nwọn lè bọ lọwọ́ idajọ igbẹsan, ki nwọn sì lè jẹ alafia imọlẹ ti kọ nipẹkun.

DIES IRÆ

Ojọ́ ibinu li ijọ́ nà ti gbogbo aiye yio pada dì èrù, gẹgẹbi ọ̀rọ ti Dafidi ati Sibilla ti sọ tẹlẹ! — Bi ibẹ̀ru awọn enia yio ti pọ̀ to, nigbati onidajọ wọn mbọ̀ wá lati wadi gbogbo iṣẹ wọn lẹsọlẹsọ! — Iró ìpe t'o lèru, t'o dún lọ titide isalẹ awọn isà okú, yio lé gbogbo awọn okú kuro ninu rẹ̀ lọ siwaju itẹ́ idajọ. — Gbogbo ìwa-ẹdá, ani ikú pâpâ, yio wà ninu ibẹrubojo, nigbati ao jí awọn okú dide lati da onidajọ wọn lohùn. — Ao ṣí iwe nâ silẹ, ninu eyi ti vio ṣe ọ̀ran idajọ t'o lẹ̀ru yi. — Nigbanâ nigbati onidajọ ba joko lori itẹ́ rẹ̀, li ao fi gbogbo ohun ikọkọ t'o lumọ julọ hàn nigbangba, ki ẹṣẹ kán má ṣe duro l'aigbẹsan l'ara rẹ̀. — Emi

otosi ẹlẹṣẹ, kil'emi yio wi nigbanà? Tani emi o bè lati ṣipẹ fun mi, nigbat'awọn olododo pâpâ yio fi iberubojo farahàn niwaju onidajọ? — Ọba olitobi ailàla ati onibẹru, Iwọ ẹnit'o gbà awọn ayanfẹ rẹ là l'ọfẹ, gbà mi là, Iwọ olorisun ânu. — Jesu alànu, ranti pe nitori mi l'Iwọ ti sokalẹ lat'ọrun wá, má ṣe da mi l'ẹbi egbé ainipẹkun l'ijọ nâ. — Arẹ ti mu Ọ ni wiwá mi kiri, Iwọ sì ti ra mi pada nipa ikú rẹ lori agbelebu, má ṣe jẹ ki ijiya ati ikú rẹ yi, jẹ asán fun mi. — Onidajọ t'ò gbẹsàn l'ododo, má ṣe duro de ojọ idajọ nâ lati dari ẹṣẹ mi jì mi. — Bi ẹlẹbi l'emi nkẹdun niwaju rẹ, oju tì mi nitori ẹṣẹ mi; mo mbè Ọ, Ọlọrun, darijì mi. — Iwọ ti darijì Maria, obiri ẹlẹṣẹ, Iwọ sì ti fi oju ânu rẹ l'emi sì ngbẹkẹle pẹlu, má ṣe jẹ ki igbẹkẹle mi d'asán. — Adura mi kò yẹ k'Iwọ gbọ́ ọ, ṣugbọn inurere rẹ ailopin mu mi reti pe Iwọ o pa mi mọ́ kuro ninu iná ainipẹkún. — Oluwa, yọ́ mi kuro ninu awọn ewurẹ ti Iwọ ṣa fi, k'o sì kà mi sinu iyè awọn agutan, ti Iwọ ti sibi ọwọ́ ọtún rẹ. — Má ṣe kó mi mọ́ awọn ẹni-egbé, ti a da l'ẹbi iná ainipẹkún, ṣugbọn gbà mi sinu iyè awọn ayanfẹ rẹ. — Mo fi irẹlẹ wolẹ niwaju Ọlá nlá rẹ. ati pẹlu irobanujẹ ọkàn t'o fẹrẹ dì êru, l'emi mbẹbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, k'Iwọ k'o ṣe itoju opin ikẹhin mi. — Si ọjọ yi ti l'ẹru to, ti awọn enia ẹlẹbi yio jinde kuro n'isà okú lati ṣe idajọ wọn gẹgẹbi iṣẹ wọn! — Ọlọrun ânu, darijì wọn. Oluwa Jesu, Iwọ t'o kún fun inu rere, fun wọn l'isimi ti kò nipẹkún. Amin.

Ihin rere (Joh. 11)

Nigbanâ ni Martha wi fun Jesu pe : Oluwa, ibaṣepe Iwọ ti wà nihin arakọnri mi k'iba kú ; ṣugbọn nisisiyi nâ, emi mọ pe ohunkohun ti Iwọ ba bère lọwọ Ọlọrun, Ọlọrun yio fi fun Ọ. Jesu wi fun u pe : arakonri rẹ yio tún jinde. Martha wi fun U pe : emi mọ pe yio tún jinde li ajinde ati iyè ẹnit'o ba gbà mi gbọ, bi o tilẹ kú yio yè. Ẹnikẹni t'o ba si wà l'âye, t'o ba si gbà mi gbọ kì yio kú titi lailai. Iwọ ha gbà eyi gbọ bi ? O wi fun U pe : bẹni, Oluwa, emi gbagbọ pe Iwọ ni Kristi ọmọ Ọlọrun alâye, ẹnit'o ti wá s'aiye yi.

Ifitọrẹ. Oluwa Jesu-Kristi, ọba ogo, gbà ẹmi ti gbogbo awọn onigbagbọ t'o ṣe alaisi kuro ninu ijiyà ibi ináwẹnumọ ati kuro ninu isalẹ adagun ; gbà wọn kuro l'ẹnu kiniu, ki orun-apâdi má ba gbé wọn mì, ki nwọn má si ba ṣubu sinu òkunkun ipo t'o l'ẹru yi, ṣugbọn jẹ ki olori awọn Angeli, Mikaẹli mimọ, ọlọpagun, mu wọn lọ sibi imọlẹ mimọ ti Iwọ ti ṣe ileri nigbani fun Abrahamu ati iran rẹ. Nitori eyi nâ ni a rù adura ati ẹbọ iyìn wá si Ọ, Oluwa, gbà wọn fun awọn ẹmí nâ ti a nṣe iranti wọn loni, k'o si jẹ ki nwọn ti ikú kuro lọ si ìye, ti Iwọ ti ṣe ileri nigbani fun Abrahamu ati iran rẹ.

Adura ti a hà jẹjẹ

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, fi ojurere gbà awọn ẹbọ yi ti a rù si Ọ fun ẹmí awọn ọmọ-ọdọ rẹ, t'ọkọnrin t'obirin, pe bi Iwọ ti fun wọn

l'itoye igbagbó kristiani, bệgẹgẹ ni k'Iwọ fun wọn l'ẹsan rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa jẹ k'imọlẹ ainipẹkun hàn fun wọn titi lai pẹlu awọn enia-mimọ́ rẹ, nitoriti Iwọ ṣeun. Oluwa fun wọn l'isimi ainipẹkun, k'Ó sì jẹ ki imọlẹ ainipẹkun hàn fun wọn titi lai, pẹlu awọn enia-mimọ́ rẹ, nitoriti Iwọ ṣeun.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, jẹ k'adura ti awa nfi irẹlẹ gbà lè ṣe anfani fun ẹmi awọn ọmọ-ọdọ rẹ, t'ọkọnri t'obiri pe, nigbat'a ti yọ wọn kuro ninu ìde èṣẹ wọn, ki nwọn lè jẹ alabapin ninu eso idandè rẹ ; Iwọ t'Ó jẹ Olọrun, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Olọrun Baba, ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ́, aiye ainipẹkun. Amin.

LIBERA ME

Oluwa, gbà mi kuro ninu ikú ainipẹkun n'ijọ́ t'o l'ẹ̀ru to bayi, nigbati ọrun on aiye yio wariri, t'Iwọ sì mbọ̀ wá lati ṣe idajọ aiye ati lati fi iná pa a run. Oluwa, mo wariri, ẹ̀ru sì bà mi, nigbati idajọ t'o l'ẹ̀ru yi ba mbọ̀ wá, ti ọrun on aiye yio wariri, ti Iwọ sì mbọ̀ wá lati ṣe idajọ aiye ati lati fi iná pa a run. Ọjọ́ nâ ni ijọ́ ibinu, ipọnju ati ọ̀si, ọjọ nla ati ijọ́ kikorò. Oluwa, fun wọn l'isimi ainipẹkun, k'o sì fi imọle ainipẹkun hàn wọn.

ADURA
OJOJUMỌ TI MISA FUN AWỌN OKU

Gbogbo awọn adura ri bâkannâ bi ti ijọ isinkú afi awọn t'o tẹle eyi.

Adura fun ẹnikan t'o ṣe alaisi.

Oluwa, dẹ eti rẹ silẹ si adura wa, ti awa nfi tọrọ ânu rẹ, k'Iwọ fi ẹmi ọmọ-ọdọ rẹ ẹniti Iwọ pasẹ fun lati ṣi kuro ninu aiye yi sibi alafia ati imọlẹ, k'o sì jẹ k'a gbà a sinu ẹgbẹ awọn enia mimọ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun awọn Bisọpu ati saserdoti t'o ṣe alaisi.

Ọlọrun, Iwọ ẹnit'o gbà awọn iransẹ rẹ sinu iyè awọn saserdoti apostoli, t'o sì fi oyè ati agbara bisọpu (tabi saserdoti) wọ̀ wọn, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ k'a gbà wọn pẹlu sinu ẹgbẹ wọn ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun awọn ibatan at'olôre wa,

Ọlọrun, Iwọ ẹnit'o wù lati fun ni ni idarijì, t'o sì fẹ igbalà awọn enia, awa mbẹbẹ lọdọ ânu rẹ, nipa ẹbẹ Maria alabukún, lailai wundia, ati nipa ti gbogbo awọn enia-mimọ, jẹ ki awọn arakọnri, ati ibatan, awọn olòre, ati gbogbo awọn ará ile wa, t'o ṣi kuro ninu aiye yi, ki nwọn lè jẹ alajopin ninu alafia ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Ọluwa wa. Amin.

Adura fun gbogbo awọn okú.

Olọrun, ẹlẹda ati olurapada gbogbo awọn onigbagbọ, fun ẹmi awọn ọmọ-ọdọ rẹ, t'ọkọnri t'obirin, ni imukuro gbogbo awọn ẹṣẹ wọn, pe nipa adura ti awa nfi irẹlẹ gbà, ki nwọn lè ri idariji ti nwọn mâ fẹ nigbagbogbo gbà lọdọ rẹ, Iwọ t'O wà, t'O sì jọba, aiye ainipẹkun. Amin.

Adura fun okú nigbat'o dì ọdún kan ti o ti kú.

Oluwa, Olọrun ânu, fun ẹmi awọn ọmọ-ọdọ rẹ, t'ọkọnrin t'obirin, ti a nṣe iranti ojọ ọdún ti ikú wọn ni ôre-ọfẹ lati wọ inu ibi itura, ibi isimi alafia, ati ibi ogo imọlẹ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ifihàn 14).

N'ijọ nâ ni mo gbọ ohùn kan lati ọrun wá nwí fun mi pe: Kọwe, alabukún fun li awọn okú t'o kú ninu Oluwa. Latihinlọ, li Ẹmi wi, ki nwọn ki o lè simi kuro ninu lâlâ wọn, nitori iṣẹ wọn ntọ wọn lẹhin.

Ihin-rere (Joh. 6).

Nigbanâ ni Jesu wi fun awọn Ju: Emi ni onjẹ âye, ẹnit'o ti ọrun sọkalẹ wá. Ẹnikẹni t'o ba jẹ ninu onjẹ yi, yio wà titi lailai; onjẹ nâ ti emi o fifun li ara mi fun iyè araiye. Nitorinâ ni awọn Ju ṣe mba ará wọn jiyan, nwọn sì wipe: bawo ni eleyi ti ṣe lè fi ara rẹ fun wa lati jẹ? Nigbanâ ni Jesu wi fun wọn pe: Lôtọ,

lôtọ ni mo wi fun nyin : Bi ẹnyin kò ba jẹ ẹran ara Ọmọ Enia, ti ẹnyin kò ba si mu ẹjẹ rẹ, ẹnyin kì yio ni iyè ninu nyin. Ẹnikẹni t'o ba jẹ ara mi, t'o ba si mu ẹjẹ mi, o ni iyè ti kò nipẹkun ; Emi o si jí i dide lọjọ ikẹhin.

L'ijọ iranti ti gbogbo awọn okú.

Gbogbo awọn adura ri bakannâ bi t'ijọ isinkú, afi awọn t'o tẹle eyi.

Epistoli (1. kor. 15).

Ará, kiyesi, ọrọ ijinlẹ ni emi o sọ fun nyin, gbogbo wa yio tún jinde nitôto, ṣugbọn gbogbo wa l'a kì yio pa lara da. Lọgán, ni iṣẹju kan, nigba ìpe ikẹhin, nitori ìpe o dún, ao si pa wa lara da. Nitoripe o tọ ki ara idibajẹ yi mu aidibajẹ wọ, ki ara ikú yi si mu aikú wọ. Nigbati ara ikú yi ba si ti aikú yi wọ tán, nigbanâ li ọrọ yi ti iwe mimọ yio ṣẹ pe ! A ti gbé ikú mì ni iṣẹgun Ikú iṣẹgun rẹ dà ? Ikú, oró itani rẹ dà ? Ṣugbọn oró itani ikú li èṣẹ, ati agbara èṣẹ ni ofin. Nitorinâ ọpẹ ni fun Ọlọrun, ẹniti'o fun wa ni iṣẹgun nipa Jesu-Christ Oluwa wa.

Ihin-rere (Joh. 5).

Lôtọ, lôtọ ni mo wi fun nyin, wakati mbọ, o si de tán nisisiyi, nigbati awọn okú yio gbọ ohùn Ọmọ Ọlọrun ; awọn ti o ba si gbọ, yio yè, nitoripe gẹgẹbi Baba ti ni iyè ninu ara rẹ, bẹgẹgẹ, ni o si fifun Ọmọ lati ni iyè ninu ara rẹ, o si fun U li agbara lati mâ ṣe idajọ pẹlu, nitoriti iṣe Ọmọ Enia, ki ẹnu máṣe yà nyin si eyi ; nitoripe wakati nà mbọ ninu eyiti gbogbo

awọn t'o wà ni isà okú ni yio gbọ́ ohùn Ọmọ Ọlọrun ; awọn ti o sì ṣe rere, yio jinde si ìye, awọn ti o sì ṣe buburu, yio jinde s'ẹbi wọn.

ADURA

Fun awọn ọjọ Ọlọrun li ọdún.

Nigbati ọdún mimọ́ ti Enia-Mimọ́ kan bọ́si ij'ọsẹ a kò kà misa ti ijọ́ nâ ; a kà Ihin rere ti ijọ́ nâ lẹhin misa, a sì kà awọn adura Kollekti Sekreta ati Post-Komunioni ti ijọ́ nâ nikanṣoṣo.

IJỌ ỌṢẸ EKINI NI ADFENDI

(Wiwá Oluwa.)

Ipilẹṣẹ tì misa. Iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si ; Ọlọrun mi, Iwọ l'emi gbẹ̀kẹle : Máṣe jẹ ki oju tì mi, bẹ̀ni máṣe jẹ kí awọn ọtá mi yọ̀ mi, nitori oju kì yio tì ẹnikẹni t'o fi sùru durode Ọ. (Ps. 24.) Oluwa, fi ọ̀na rẹ hàn mi, k'o sì kọ́ mi ni ipa-ọ̀na rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, fi agbara rẹ hàn, k'O sì wá, ki nipa âbo rẹ k'a lè gbà wa kuro ninu tulasin ti ẹ̀ṣẹ wa fà wa si, k'a sì lè gbà wa là nipasẹ Iwọ Olugbalà wa, Iwọ t'O jẹ

Ọlọrun, t'O wà t'O sì jọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Iranti ti Maria mimọ.

Oluwa, Iwọ t'o fẹ ki Ọrọ rẹ di ẹran ara ninu Maria Wundia mimọ nipa iṣẹ riran lat'ọwọ Angẹli kan wá, fifun adura wa, pe bi a ti ngbagbọ pe iyá Ọlọrun ni on ṣe nitôtọ, nipa ẹbẹ rẹ l'ọdọ rẹ k'a lè fi iran wa lọwọ.

Adura fun Eklesia.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ojurere gbà adura Eklesia rẹ pe. nipa bibọ l'ọwọ gbogbo ipọnju ati ẹkọkẹkọ, ki o lè mà fi irọrun ati idakẹjẹ sìn Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun Papa mimọ.

Ọlọrun Olusọ ati alakoso gbogbo awọn onigbagbọ, fi ojurere wò Iranṣẹ rẹ, ẹniti Iwọ fi si isọ Eklesia rẹ, fifun u, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, ki nipa ọrọ ati apẹrẹ, k'o lè ma tọ awọn ẹniti on sẹ olori wọn s'ọna rere, k'on ati gbogbo agbo t'a fi ṣọ, lè de ibi ìye ainipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. 13).

Ẹnyin ará mi, ẹ mọ pe wakati ti de lati jí loju orun, nitori isisiyi ni igbalà wa sunmọ etile jù ìgbati awa ti gbagbọ lọ. Oru bukoja tán, ọsán kù si dẹdẹ; nitori nâ ẹ jẹ k'awa bọra iṣẹ òkunkun silẹ, k'a sì di ihamọra imọlẹ. Jẹ k'awa ma fi ìwa pẹlẹ ati ìwa yiyẹ rin bi

l'ọsán. Ẹ máṣe fi ara nyin fun iwọbia, ati fun ọti amupara, tabi fun iṣagbere ati fun aiye jijẹ, tabi fun ija ati ilara, ṣugbọn ẹ mu Oluwa Jesu-Kristi wọ.

Graduali Oluwa, oju ki yio tì ẹnikẹni t'o fi sùru duro de Ọ. Ọlọrun, fi ọna rẹ hàn mi, k'O sì kọ́ mi ni ipa ọna rẹ. Alleluia, alleluia (Ẹ má yìn Ọlọrun) Oluwa, fi ànu rẹ hàn fun wa, k'O sì fun wa ni igbalà rẹ, alleluia..

Ihin rere (Luk. 21).

Nigbanâ ni Jesu wi fun awọn ọmọ ẹhin rẹ pe : àmi yio sì wà li ôrun ati li oṣupa, ati li irawọ ati, l'aiye, iberu nla ati idâmu lârin awọn orilẹ-ède nitori ihó t'o l'ẹru ti ôkun ati riru omi. Aiya enia yio mâ já fun ibẹru, ati fun iwoye nkan wọnyi ti mbọ̀ wá si aiye, nitori awọn agbara ọrun li ao mì-titi. Nigbanâ ni nwọn o si ri Ọmọ-enia ti yio mâ bọ̀ ninu awọsanma, ti on ti agbara ati ogo nla. Nigbati nkan wọnyi ba bẹrẹsi iṣẹ, ẹ mâ wò oke, k'ẹ sì gbé ori nyin soke. nitori idándè nyin kù si dèdè. O sì pa owe kan fun wọn pe : Ẹ kiyesi igi opọtọ ati gbogbo igi. Nigbati nwọn ba. mruwé, ẹnyin mọ̀ fun ara nyin pe, ìgba-êrun kù si dèdè. Bẹ̀gẹ̀gẹ̀ ni ẹnyin, nigbati ẹnyin ba ri nkan wọnyi ti nṣẹ, ki ẹnyin k'o mọ̀ pe ijọba Ọlọrun kù si dèdè. Lótọ̀ ni mo wi fun nyin pe : iran yi ki yio rekọja titi ao fi mu gbogbo nkan wọnyi ṣẹ. Ọrun on aiye yio rekọja, ṣugbọn ọ̀rọ̀ mi ki yio rekọja.

Ifitọrẹ. Iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si,

Olọrun mi, Iwọ l'emi gbẹkẹle : Máṣe jẹ ki oju tì mi, bẹni máṣe jẹ ki awọn ọtá mi k'o yọ mi, nitori oju kì yio tì ẹnikẹni t'o fi sùru durode Ọ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, Iwọ t'o fi agbara nla wẹ wa mọ, nipa ẹbọ mimọ yi jẹ k'a lè dì mimọ si i lati de ibi orisùn rẹ, nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi Ọmọ rẹ, t'O wà, t'O si jọba pẹlu Iwọ ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ, Olọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

Iranti ti Maria mimọ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ẹsẹ ọrọ ijinlẹ ti igbagbọ tọtọ mulẹ ninu ọkàn wa pe, b'a ti njẹwọ Olọrun ati enia tọtọ ti Wundia kan l'oyún, k'awa lè yẹ nipa agbara ajinde rẹ t'o mu igbalà wá, lati de ibi ayọ ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi nâ, Oluwa wa. Amin.

Adura fun Eklesia.

Oluwa, dâbobo awa ti nṣe iṣẹ ọrọ ijinlẹ rẹ ki, nipa fi'fara wa fun olùn mimọ. k'a lè fi ọkàn ati ara wa sìn Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun Papa mimọ.

Oluwa jẹ ki ẹbọ t'a rù si Ọ tù Ọ l'inu, k'o si fun Iranṣẹ rẹ N. ẹniti Iwọ fi ṣe oluṣọ Eklesia rẹ ni âbo rẹ titi lọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa yio da ibukún rẹ si wa lori, ilẹ yio si mu eso rẹ jade wá.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ k'a ri ânu rẹ gbà ninu ile rẹ mimọ, k'awa lè mura bi o ti yẹ si ọdún mimọ ti igbalà t'o kù si dèdè; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Iranti ti Maria mimọ.

Oluwa, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, tú ôre-ọfẹ rẹ si wa l'ọkàn pe, b'awa ti mọ iṣọ d'enia ti Ọmọ rẹ Jesu-Kristi nipa iṣẹriran lat' ọwọ́ Angẹli kan wá, bẹgẹgẹ nipa agbelebu ati ijiya rẹ, k'a lè mu wa wá s'ibi ogo ajinde rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Adura fun Ekiesia.

Oluwa, Ọlọrun wa, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, máṣe jẹ ki awa t'Iwọ fi alafia fun lati pin ninu sakramenti rẹ mimọ, ṣugbọn sinu tulasin ti ìwa enia terisi.

Adura fun Papa mimọ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki sakramenti mimọ ti awa ti gbà, ki o lè dàbobo wa, k'o sì lè jẹ âbo ati igbalà fun Iransẹ rẹ N. eniti Iwọ fi ṣe oluṣọ Eklesia rẹ, ati fun gbogbo agbo ti a fi ṣọ, nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa, Ọmọ rẹ, t'O wà, t'O sì joba pẹlu Iwọ ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ, Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

IJỌ ỌSẸ EKEJI ADFENTI

Ipilẹṣẹ ti misa. Ẹnyin enia mi, Sioni, kiyesi i, Oluwa nyin mbọ wá lati gbà awọn keferi là.

Oluwa yio sì mu ki a gbó ohùn ogo rẹ, ẹnyin yio sì yọ. Ps. Fetisi wa, Ọlusọ́-agutan Israẹli, Ìwọ tí Ó ndà Josefu bi agutan. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, sọ ọkàn wa já lati tún ọna Ọmọ bíbi rẹ nikanṣoṣo ṣe, ki awa ti a wẹ mọ́ l'ọkàn nipa wiwá rẹ, k'o lè yẹ lati sìn Ọ ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Lẹhinnâ a ṣe iranti Maria mimọ́, etc. bi ni ijọ́ ọsẹ ekini

Epistoli (Rom. 15).

Ẹnyin ará mi : Ohunkohun ti a kọwe rẹ, a ti kọ ọ fun kikọ́ wa, ki awa, ti ipa sùru ati itùnu ti Iwe mimọ́, k'o lè ni ireti. Njẹ ki Ọlọrun sùru ati itùnu ki O fifun nyin lati ṣe inu kan si ara nyin gẹgẹbi ẹkọ́ Jesu-Kristi, ki ẹnyin ki o lè fi ọkàn ati ẹnu kan yìn Ọlọrun, Baba Jesu-Kristi Oluwa wa logo. Nitorinâ, ẹ fiyesi ará nyin gẹgẹbi Jesu-Kristi ti ṣe si wa fun ogo Ọlọrun. Mo sì wipe Jesu-Kristi ti jẹ iranṣẹ Ihin rere sipa ti awọn Ju ti a kọ nilà nitori otitọ Ọlọrun, lati mu ileri nâ duro t'a ti ṣe fun awọn baba wọn. Ṣugbọn bi o ṣe ti awọn keferi ni, ki nwọn k'o nyìn Ọlọrun logo nitori ânu rẹ, gẹgẹ bi a ti kọwe rẹ pe : Nitori nâ l'emi o ṣe fi iyìn fun Ọ, Oluwa, ninu awọn keferi, emi o sì kọrin iyìn si Orukọ rẹ. Iwe mimọ́ sì tún wipe : Ẹ ma yọ, ẹnyin orilẹ-ede, pẹlu awọn enia rẹ. Ati pẹlu : Ẹ ma yìn Oluwa, ẹnyin orilẹ-ede gbogbo, ẹ sì ma yìn I logo, ẹnyin enia gbogbo. Isaia si tún wipe : L'at'inu gbòn-

gbo Jesse ilàhu kan yio jade wá, ti yio dide lati jọba lori awọn orilẹ-ede, On l'awọn orilẹ-ede yio gbẹkẹle. Njẹ, ki Olọrun ireti k'o kún nyin fun gbogbo alafia ati ayọ ninu igbagbọ nyin, ki ẹnyin lè pọ ni ireti nipa agbara Ẹmi-Mimọ.

Graduali. Lati Sioni idanṣanṣan ogo rẹ yio ade wá. Olọrun mbọ nigbangba. Ẹ kó awọn enia mimọ rẹ jọpọ niwaju rẹ, awọn t'o ba A da majẹmu niti awọn ẹbọ. Alleluia, allelaia. *Ps.* Inu mi dùn nigbati nwọn wi fun mi pe : Ao lọ s'ile Oluwa alleluia.

Ihin rere (Mat. 11).

Nigbati Johanu gbọ iṣẹ Kristi ninu tubu, o ran awọn ẹnọ rẹ meji lati wi fun U pe : Iwọ ha li ẹniti mbọ tabi ki a ma reti ẹlomiran? Jesu si dahùn wi fun wọn pẹ : Ẹ pada lọ, k'ẹ si rohin ohun wọnyi t'ẹnyin gbọ, at'eyi t'ẹnyin ri fun Johanu : awọn afọju nriran, awọn amôkun nrin ṣaṣa, awọn adẹtẹ l'a nwẹ mọ, awọn aditi gbọran a nji awọn okúdide fun awọn talaka l'a nwàsu Ihin rere, alabukún fun si li ẹnikẹni ti kì o mu ọna atidẹṣẹ nitori mi. Nigbati nwọn si lọ, Jesu bẹrẹsi isọrọ ti Johanu fun awọn enia pe: kini ẹnyin jade lọ wò li aginjù? Esú ti nmì fun afẹfẹ? Ani kini ẹnyin jade lọ wò? Okọnrin ti a wọ l'aṣọ fúlefúlẹ? Ṣugbọn awọn ẹniti nwọ aṣọ fúlefúlẹ mbẹ li atin ọba. Njẹ kili ẹnyin jade lọ wò? Woli? Lòtọ ni mo wi fun nyin, o si jù woli lọ. Nitori on ni ẹniti a kọwe nitori rẹ pe : Wò o, mo ran Angẹli mi siwaju rẹ, eniti yio tún ọna rẹ ṣe niwaju rẹ.

Ifitọrẹ. Ọlọrun. Iwọ o yipada si wa, Iwọ o sì tún sọ wa di alaye, awọn enia rẹ yio sì mâ yọ̀ ninu rẹ. Oluwa, fi ânu rẹ hàn fun wa, ki o sì fun wa ni igbalà rẹ.

Adura ti a mâ kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, jẹ ki adura ati ẹbọ yi ti awa fi irẹlẹ rù sì Ọ, ki o tù Ọ ninu, atipe bi awa kò ti ni itoye fun ara wa, nipa ânu rẹ k'o fiyesi i lati ran wa lọwọ́ titi, nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

Lẹhinnâ a ṣe iranti Maria mimọ́, etc.. bi li ijọ́ ọsẹ ekini.

Kommunioni. Dide, Iwọ Jerusalemu, ki o sì duro lori oke, kio sì kiyesi ayọ̀ ti o t'ọdọ Ọlọrun wá sọdọ rẹ.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa ti o kún fun onjẹ t'ẹmí, nfi irẹlẹ bẹ̀bẹ lodọ rẹ, nipa ibapin ninu ọ̀rọ ijinlẹ yi, kọ́ wa lati mâ gàn ohun t'aiye yi, k'a sì mâ fẹ ohun t'ọrun ; nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

Lẹhinnâ a mâ ṣe iranti Maria mimọ́, etc., bi li ijọ́ ọsẹ ekini.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸTA NI ADFENTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ mâ yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo, mo tún wipe : ẹ ma yọ̀. Ẹ jẹ ki iwa pẹlẹ nyin di mimọ̀ fun gbogbo awọn enia : Oluwa kù si dẹ̀dẹ̀. Ẹ má ṣe daro ohunkohun, ṣugbọn nipa adura ati ẹ̀bẹ̀ pẹlu idupẹ ẹ ma fi ibère nyin hàn fun Oluwa l'ohun gbogbo.

Ps. Oluwa Iwọ ti bukún fun ilẹ rẹ, Iwọ ti gbà Jakobu là lat'inu igbekun rẹ̀. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ l'ọdọ rẹ, dẹ eti rẹ silẹ si adura wa ati, nipa òre-ọfẹ ibẹ̀wò rẹ, fiyesi i lati tan'mọlẹ si òkunkun ọkàn wa ; Iwọ t'Ó wà, t'O sì jọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ́, Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (Fil. 4).

Ẹnyin ará mi, ẹ ma yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo, mo tún wipe : ẹ ma yọ̀. Ẹ jẹ ki iwa pẹlẹ nyin di mimọ̀ fun gbogbo enia : Oluwa kù si dẹ̀dẹ̀. Ẹ má ṣe daro ohunkohun, ṣugbọn nipa adura ati ẹ̀bẹ̀ pẹlu idupẹ, ẹ ma fi ibère nyin hàn fun Oluwa l'ohun gbogbo ; ki alafia Ọlọrun t'o jù imoran lọ k'o sì pa nyin l'aiya ati ọkàn mọ́ ninu Jesu-Kristi.

Graduali. Oluwa, Iwọ t'o joko l'ori awọn Kerubimu, fi agbara rẹ hàn, k'o sì wá. Fetisi ni, Oluṣọ́ agutan Israeli, Iwọ t'o nda Josẹfu bi agutan Alleluia, alleluia.

Oluwa, fi agbara rẹ hàn, k'o sì wá lati gbà wa là. Alleluia.

Ihin rere (Joha I, 19).

Nigbanâ ni awọn Ju rán awọn alufa ati Lefiti sọdọ Johanu lati Jerusalemu wá, lati bi i lẽre wipe : Tani iwọ ṣe? On sì jẹwọ, kò sì sẹ, ṣugbọn o jẹwọ pe : Emi kì iṣe Kristi nâ. Nwọn sì bi i lẽre wipe : Tani iwọ ṣe? Iwọ ha ṣe Eliasi bi? O sì wipe : Emi kì iṣe on Iwọ ni Woli nì bi? O sì dahùn wipe : Bẹ̀kọ. Nje tani iwọ ṣe, ni nwọn wí fun u, ki awa ki o lè fi èsi fun awọn ti o rán wa? Kini iwọ wi niti ara ti kalarẹ? O wipe : Emi ni Ohùn ti nkigbe li aginjù : E tún ọna Oluwa ṣe, gẹgẹbi Woli Isaia ti wí. Awọn ti a rán sì jẹ ẹgbẹ Farisi, nwọn sì bi i lẽre, nwọn sì wi fun u pe : èṣe ti iwọ fi mbatisi bi iwọ kì ba ṣe Kristi nâ tabi Eliasi tabi Woli nì? Johanu da wọn lohùn wipe : Emi nfi omi batisi; ṣugbọn ẹnikan duro lârin nyin, eniti ẹnyin kò mọ : on nâ li eniti mbọ̀ lẹhin mi, t'o wà ṣiwaju mi, okùn bàta ẹsẹ eniti emi kò yẹ lati tú. Nkan wonyi li a ṣe ni Betania loke odò Jordani.

Ifitọrẹ. Oluwa, Iwọ ti bukún fun ilẹ rẹ; Iwọ ti gbà Jakobu là lat'inu igbekun rẹ̀; Iwọ ti dari ẹṣẹ awọn enia rẹ jì.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki awa mâ fi ifọkànsìn rù ẹbọ yi si Ọ nigbagbogbo, kì o lè

seso nâ ninu wa nitori eyiti Iwọ ti da ọrọ ijinlẹ mimọ́ yi silẹ, ki o sì lè fi iyanu sọ́n isẹ́ igbalà, ti Iwọ ti jère fun wa siwaju ninu wa, nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹ wi fun awọn alailaiya pe : ẹ mu aiya le, k'ẹ má sì ṣe bẹ̀rù : wò o, Ọlọrun wa mbọ̀, yio sì gbà wa là.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ l'ọdọ ânu rẹ, jẹ ki ọrọ ijinlẹ mimọ́ yi t'o wẹ̀ wa nù kuro ninu èṣẹ wa, k'o lè mu wa mura b'o ti yẹ si ọdún mimọ́ t'o kù si dẹ̀dẹ̀; nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸRIN NI ADFENTI

Ipelẹsẹ ti Misa. Ẹnyin ọrun, ẹ kan iri silẹ lat'oke wá, k'ẹ sì jẹ ki awọn awọ́-sanma rọ̀ ododo s'ilẹ; ki ilẹ ki o là, k'o sì hù Olugbala jade. *Ps.* Awọn ọrun nrohin awọn ogo Ọlọrun, oju-ọrun sì fi iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀ hàn. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ l'ọdọ rẹ, gbé agbara rẹ dide, k'o sì wá fi agbara nla ran wa l'ọ̀wọ́, k'a lè mu igbalà wa ti èṣẹ wa dè l'ọ̀na, yara nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ, ati nipa ânu rẹ t'o pọ̀ju; Iwọ t'O jẹ Ọlọrun, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ́, aiye ainipẹkun. Amin.

Lẹhinnâ, a ṣe iranti Maria mimọ́, etc.

Epistoli (Kor. 4).

Ẹnyin ará mi, ẹ jẹ ki enia ki o ma kà wa si bi iranṣẹ Kristi ati bi olupin fun ti awọn ohun ijinlẹ Ọlọrun. Ṣugbọn a mbère l'ọdọ awọn olupinfunni pe, ki olukuluku won jẹ olododo. Bi o ṣe temi ni, ohun kekere sá ni fun mi, ti ẹnyin, tabi ẹnikẹni yio ṣe idajọ mi, ani emi kò jẹ ṣe idajọ aratikalami; nitori bi emi kò tilẹ mọ ohunkohun si ara mi nitori eyi nâ ni a kò da mi l'âre, ṣugbọn ẹniti nṣe idajọ mi li Oluwa. Nitorinâ ẹ máṣe ṣe idajọ ṣaju akoko nâ, titidi igbati Oluwa bà de, ẹniti yio mu ohun ti o farasìn ninu okunkun wá si imọlẹ, ti yio sì fi irò ìkọkọ ti ọkàn hàn; nigbanâ ni olukuluku yio sì ri iyìn rẹ gbà lọdọ Ọlọrun.

Graduali. Oluwa wà leti ọdọ gbogbo ẹniti nkigbe pè E li otitọ. Ẹnu mi yio mâ sòrọ iyìn Oluwa. ki gbogbo enia ki o sì mâ fi ibukún fun orukọ rẹ mimọ lai ati lailai, Alleluia, alleluia. Wà, Oluwa, má si ṣe pẹ; ki o dari ẹ̀ṣẹ Israeli, awọn enia rẹ, jì. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 3.)

Li ọdún kẹdogun ijọba Tiberiu Kesari, nigbati Pontiu Pilatu ṣe akoso jọba lori Judea, ti Herodu si jẹ bâlẹ Galilea, Filippi arakọnri rẹ̀ si jẹ bâlẹ Iturea, ati ti ilẹ Trakoniti, Lisania si jẹ bâlẹ Abilẹni, ti Anna on Kaifa nṣe olori awọn alufa, nigbanâ ni ọrọ Ọlọrun tọ Johanu, ọmọ Sakaria. wá li aginjù. O si wá si gbogbo ilẹ iha Jordani, o nwâsu ibatisi irò-

nupiwada fun imukuro èṣẹ, bi a ti kọ ọ ninu iwe òrọ Woli Isaia pe : Ohùn ẹniti nkigbe ni ijù : E tún ọna Oluwa ṣe, ẹ mu ipa ọna rẹ tọ. Gbogbo afonifoji li ao kún, gbogbo òke nla ati òke kekere li ao tẹ-bẹrẹ. awọn ọna korọ-korọ ti ao ṣe ni titọ. ati ọna palapala li ao sọ di kikunna. Gbogbo enia yio si ri igbalà Ọlọrun.

Ifitorẹ. Mo ki Ọ, Maria, O kún fun ôre-ọfẹ, Oluwa mbẹ pẹlu rẹ, alabukún fun ni Iwọ ninu awọn obinri, alabukún fun si ni eso inu rẹ.

Adura ti a ha jeje.

Oluwa, awa mbèbẹ lodọ rẹ, je ki ebọ t'o wà nihin yi ki o tù Ọ l'inu, k'Iwọ k'o si f'ojurere wò o, k'o si lè ṣ'anfani fun ifọkànsìn wa ati fun igbalà wa ainipẹkun ; nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

Komunioni. Kiyesi i, Wundia kan yio l'oyún, yio si bí ọmọ-kọnri kan, yio si pè orukọ rẹ ni Emanuẹli.

Adura lehin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ l'odọ rẹ, nipa ṣiṣe iṣẹ ohun ijinlẹ yi nigbakugba, je ki iṣẹ igbalà k'o lè pọ si i ninu awa t'a ti ri ọpọ èbun to bayi gbà ; nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

ỌDUN MIMỌ TI IBÍ JESU-KRISTI, TABI NATALI

Misa ekini l'ọganjọ.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa ti wi fun mi pe : Iwọ ni Ọmọkọnrin mi, l'oni ni mo bí Ọ. *Ps.* Ẹṣe ti awọn keferi fi ṣ'ọtẹ, ti awọn enia sì nbiro ohun asán ? Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun, Iwọ t'o tàn imọlẹ si oru mimọ julọ yi, nipa ibí Imọlẹ tôtọ, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, ti ôre-ọfẹ fun wa pe, bi awa ti mọ òro ijinlẹ ti Ọrọ rẹ t'o di Enia l'aiye yi, k'awa lè jẹ alabapin l'ọrun rere ninu ayọ ti on fifun awọn ayanfẹ rẹ ; Eniti'O jẹ Ọlọrun. t'O wà, t'O sì joba pẹlu Iwọ, ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (Titu 2).

Olufẹ mi, ôre-ọfẹ Ọlọrun Olugbala wa ti hàn fun gbogbo awọn enia, O sì kọ wa lati kọ aiwa bi-Ọlọrun ati ifẹkufẹ aiye silẹ, ati lati mâ wà li iwontunwonsin, li ododo ati li ìwabi-Ọlọrun l'aiye isisiyi, niwọn igbat'a mâ woye ireti t'o ni ibukún ati wiwa t'o logo ti Ọlọrun ti O tobi ati ti Jesu-Kristi Olugbala wa, eniti O fi ara rẹ fun wa, ki on ki o lè rà wa pada kuro ninu ẹṣẹ gbogbo, ki o sì lè wẹ wa mọ lati sọ wa di enia iyasọtọ fun isìn rẹ, nipataki ati onitara ninu iṣẹ rere. Nkan wọnyi ni ki iwọ ki o mâ sọ, ki o sì mâ gbà ni niyanjú : ninu Kristi Jesu Oluwa wa.

Graduali. Lọdọ rẹ ni ijọba yio wà li ọjọ agbara rẹ, nigbati iwọ o farahàn ninu ẹwa iwa mimọ rẹ. Emi ti bí Ọ lat'inu mi wá, ki emi t'o dá irawọ-owurọ Oluwa wi fun Oluwa mi pe : Joko li ọwọ ọtún mi titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti-itisẹ rẹ. Alleluia, alleluia. Oluwa wi fun mi pe : Iwọ li ọmọkọnri mi, l'oni ni mo bí Ọ. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 2).

Nigbanâ ni aṣẹ ti ọdọ Kesari Augustu wá pe, ki a kàye enia gbogbo aiye. Kirinu, bâlẹ Siria, l'o ṣe ikàye ekini yi. Gbogbo awọn enia sì lọ olukuluku si ilú rẹ lati kọ orukọ rẹ sinu iwe. Josefu pẹlu rè oke lati ilú Nasareti ni Galili lọ si ilú Dafidi ni Judea, ti a npè ni Betlehemu, nitoriti o ṣe ti ile ati idile Dafidi, lati kọ orukọ rẹ sinu iwe pẹlu Maria aya rẹ afẹsona, ti o loyún. O si ṣe, nigbati nwọn wà nibẹ, ọjọ rẹ ti on yio bí pé. O si bí akọbí rẹ ọmọkọnri, o si fi ọja wé e, o si tẹ ẹ sinu ibujẹran, nitoriti àye kosi fun wọn ninu ile-èro. Awọn oluṣọ-agutan si nbẹ n'ilú nâ, ti o nṣaisùn ni pápa, ti o si nṣọ agbo agutan wọn olukuluku li asikò tirẹ. Sá si kiyesi i, Angẹli Oluwa yọ si wọn, imọlẹ atọrun wá si hàn yi wọn ká, ẹ̀ru si bà wọn gidigidi. Angẹli nà si wi fun wọn pe : Ẹ máṣe bẹ̀ru, sá wo o, mo mu ihin rere fun nyin wá, ti yio kún gbogbo enia fun ayọ nla, nitori ti a bí Olugbala fun nyin l'oni, n'ilú Dafidi, ti iṣe Kristi Oluwa. Eyi ni àmi ti ẹnyin o fi mọ Ọ : Ẹnyin o ri ọmọ-ọwọ nà t'a fi ọja wè, O dubulẹ ni ibujẹ ẹran. L'oja-

kannâ ọpọ̀lọpọ̀ ọmọ-ogun ọrun sì dapọ̀ mọ́ Angẹli nà, nwọn sì nyìn Ọlọrun wipe : Ogo ni fun Ọlọrun l'oke ọrun ati, l'aiye, alafia fun enia t'o ni ifẹ̀ inu rere.

Ifitọrẹ. Jẹ ki awọn ọrun ki o yọ̀, ki ilẹ aiye ki o kún fun ayọ̀ niwaju Oluwa, nitori ti o wá.

Adura t'a kà jejẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ ọdọ rẹ, tẹwọgbà ẹbọ ọdún mimọ́ t'oni yi. k'Ó sì fi ôre-ọfẹ fun wa pe, nipa isẹ̀ mimọ́ yi, k'a lè ri wa bakannâ bi ẹni ninu ẹniti ìwa wa dapọ̀ mọ́ Ọ ; ẹnit'Ó jẹ Ọlọrun. t'Ó wà, t'Ó sì jọba pẹlu Iwọ, ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ́. Amin.

Komunioni. Ninu ẹwà-ìwa mimọ́, ki afẹmọjumọ t'o wà ni mo ti bi Ọ lati inu mi wá.

Adura lẹhin komunioni:

Oluwa Ọlọrun wa, fi ôre-ọfẹ fun wa pe, bi awa ti fi ayọ̀ sẹ ọdún ibí Óluwa wa Jesu-Kristi nipa ṣiṣe ajọpin ninu ọ̀rọ ijinlẹ rẹ nighakugba nipa ìhuwa mimọ́, k'awa lè ye lati ghà wa sinu ẹgbẹ rẹ, ẹnit'Ó jẹ Ọlọrun, t'Ó wà, etc.

MISA EKEJI LI AFẸMỌJUMỌ

Ipilẹsẹ ti misa. L'oni ni imọlẹ titún yio hàn si wa, nitori a bí Oluwa fun wa, ao sì mâ pè orukọ rẹ̀ ni Ẹni iyanu, Ọlọrun, Ọmọ-alade

alafia Baba aiye ti mbộ, ijọba ẹniti kì yio nipẹkun. *Ps.* Oluwa jọba, ogo ni o wọ̀ l'aṣọ, agbara ni Oluwa wọ̀ l'aṣọ, o sì di ihamọra. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare, Iwọ ti o fi imọlẹ titún ti Ọrọ rẹ t'o di enia kan fun wa l'oni, fifuni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki imọlẹ ti o ti ipa igbagbọ́ mọlẹ ninu ọkàn wa, ki o lè tàn jade ninu isẹ wa pẹlu; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin

Epistoli (Titu 3).

Olufẹ mi, inu rere Ọlọrun, Olugbala wa, ati ifẹ rẹ si awọn enia farahàn l'aiye. O gbà wa là ki isẹ nitori isẹ ododo ti awa ti ṣe, ṣugbọn, nitori ânu rẹ, nipa iwẹnu atúnbi ati nipa ìsọdọtún Emi-Mimọ́, ti O dá sori wa lọpọlọpọ nipasẹ Jesu-Kristi Olugbala wa, pe bi a ti nda wa lâre nipa ore-ọfẹ rẹ, ki a lè sọ wa di ajogun iye ainipẹkun gẹgẹbi ireti ti awa ni ninu Jesu-Kristi Oluwa wa.

Graduali. Ibukún ni fun ẹniti o wá l'orukọ Oluwa, Oluwa li Ọlọrun tòto, o si fi imọlẹ hàn wa. Oluwa l'o ṣe eyi, ti isẹ ohun iyanu loju wa. Alleluia, alleluia. Oluwa jọba, ogo ni o wọ̀ l'aṣọ, agbara ni Oluwa wọ̀ l'aṣọ, o sì di ihamọra. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 2[1]).

Nigbanâ ni awọn oluṣọ́-agutan bá ará wọn

sọ pe : E jẹ k'a lọ si Betlehemu ki a si ri ohun t'o ṣẹ, ti Oluwa fi hàn fun wa. Nwọn si wá kánkan, nwọn si ri Maria ati Josẹfu, ati ọmọ-ọwọ nà, O dubulẹ ninu ibujẹ ẹran. Nigbati nwọn si ti ri i, nwọn ri otitọ ohun t'a ti wi fun wọn niti ọmọ yi. Ẹnu si ya gbogbo awọn t'o gbọ́ nkan wọnyi t'a rohin fun wọn lati ọdọ awọn oluṣọ́-agutan wá. Ṣugbọn Maria pa gbogbo nkan wọnyi mọ́, o si nrò wọn ninu ọkàn rẹ. Awọn, oluṣọ́ agutan si pada lọ, nwọn nfi ogo fun Ọlọrun, nwọn nyìn I nitori ohun gbogbo ti nwọn ti gbọ́ ti nwọn si ti ri gẹgẹ bi a ti wi i fun wọn.

Ifitọrẹ. Ọlọrun fi idi aiye mulẹ, ti kì yio lè mì. Nigba atijọ ni a ti fi idi itẹ rẹ kalẹ, Ọlọrun; aiyeraiye ni Iwọ.

Adura t'a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, jẹ ki ọrẹ-ẹbọ wa lè yẹ ọ́rọ-ijinlẹ t'ọdún ibí t'oni yi, k'o si lè mà da alatia rẹ sori wa nigbagbogbo pe, gẹgẹ bi Ọmọ rẹ t'a bi l'enia, ti fi ìwa-Ọlọrun rẹ hàn lojukannà, bẹ̀gẹgẹ nipa jijẹ ohun atinu ilẹ wá yi, t'a sọ di mimọ́, k'a lè sọ wa di alabapin ninu ìwa Ọlọrun ; nipasẹ Jesu-Kristi nã Oluwa wa.

Komunioni. Yọ̀ gidigidi, Iwọ ọmọbiri Sioni, hó ihó ayọ̀. Iwọ ọmọbiri Jerusalemu : kiyesi i, ọba rẹ, ẹni-mimọ́ ati Olugbala araiye mbọ̀ wá.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa jẹ k'a lè ma ri ìye titún gbà nigbagbogbo nipa sakramenti t'o sọ iranti ibí t'o ni iyanu t'ọmọ rẹ d'ọtún nipa ẹniti a ti pa ìwa enia atijọ run ninu wa, nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

MISA ẸKẸTA L'IJỌ IBÍ JESU-KRISTI

Ipilẹsẹ ti Misa. A bí ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkọnri kan fun wa; yio gbé àmi ijoba rẹ lori ejika rẹ, ao sì mâ pè orukọ rẹ ni Àngẹil igbimọ nla. *Ps.* Ẹ kọrin titún si Oluwa, nitoriti o ti ṣe ohun iyanu. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, fifuni, ki ibí titún ti Ọmọ bibí rẹ nikanṣoṣo ki o lè dá wa nidè kuro ninu àjaga ẹṣẹ, labẹ eyiti oko-ẹrú atijọ ti mu wa dáni; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Heb. 1.

Nigba pupọ ati li onirûru ọna ni Olọrun ti ipa awọn Woli bá awọn baba sọrọ nigbani, nikẹhin li ojó wọnyi O ti ipasẹ Ọmọ rẹ bá wa sọrọ, ẹniti O ti jẹ ajogun ohun gbogbo, nipasẹ ẹniti o ti dà aiye pẹlu; bi o si ti jẹ imọlẹ ogo rẹ ati jijọ aworan ìwa rẹ, bi o si ti nfi ọrọ agbara rẹ dì ohun gbogbo mu, lẹhin igbati O

ti wẹ wa nù ninu ẹṣẹ, O joko li oke ọrun, li ọwọ́ ọtún Olá nlanla ; ẹniti a gbé ga soke jù awọn Angẹli lọ niwonbi orukọ rẹ̀ ti o jogun ti ta tiwọn yọ to. Nitoripe tani ninu awọn Angẹli ti o wí fun nigbakanri pe : Iwọ ni Ọmọ mi, li ojó oni ni mo bí ọ? Ati pẹlu : Emi ni yio mà ṣe baba rẹ̀, on ni yio si mà ṣe Ọmọ mi? Nigbati o si tún mu Akobí rẹ̀ wá si aiye, o ni : Ki gbogbo awọn Angẹli Ọlọrun ki o sì mà foribalẹ fun U. Ati ni ti awọn Angẹli, iwe mimọ́ wi nitôtọ pe : O dá awọn Angẹli rẹ̀ li afẹfẹ, ati awọn iranṣẹ rẹ̀ li ọwọ́ iná. Ṣugbọn fun Ọmọ li O wipe : Itẹ́ rẹ. Ọlọrun, duro lai ati lailai, ọpa-alade ododo ni ọpa-alade ijọba rẹ. Iwọ ti fẹ́ ododo, Iwọ sì ti korira aiṣododo. Nitori nà ni, Ọlọrun, Ọlọrun rẹ ti ta ororo ayọ̀ si O l'ori jù awọn alabapin ninu ogo rẹ lọ. Ati pẹlu : Oluwa, lat'ipilẹṣẹ ni Iwọ ti fi ipilẹ aiye sọlẹ, awọn ọrun si n'iṣẹ ọwọ́ rẹ. Nwọn o ṣegbé, ṣugbọn Iwọ o duro, gbogbo wọn ni yio si dì ogbó bi aṣọ. ati bi agbada ni Iwọ o paro wọn, ao si paro wọn. Ṣugbọn bi o ṣe ti Iwọ ni bakannà ni Iwọ, ọdún rẹ kì yio si l'opin.

Graduali. Gbogbo opin aiye ti ri igbalà Ọlọrun wa. Ẹ hó ihó ayọ̀ si Oluwa, gbogbo orilẹ-ede aiye. Oluwa ti ṣọ igbalà rẹ̀ di mimọ̀ ; ododo rẹ̀ li o ti fihàn l'oju awọn keferi. Alleluia, alleluia. Ojó mimọ́ ti fi imọlẹ rẹ̀ fun wa. Ẹ wá, enyin keferi, k'ẹ sì foribalẹ fun Oluwa, nitori ti imọlẹ nla ti sọkalẹ wá si aiye. Alleluia.

Ihin rere nipa ti Johanu mimọ́ : Li atetekọṣe li Ọrọ wà, etc. (*wo apa 116*).

Ifitọrẹ. Tirẹ ni ọrun on aiye; Iwọ ti fi ipilẹ aiye sọlẹ pẹlu nkan gbogbo t'o wà ninu rẹ; ododo ati iṣedède ni ipilẹ itẹ rẹ.

Adura t'a kà jẹjẹ.

Oluwa nipa ibí titún ti ọmọ bibí rẹ nikan-ṣoṣo ṣọ awọn ọrẹ t'a rù si Ọ lẹbọ dì mimọ́, ki O sì wẹ wa nù ninu ahawọn ẹṣẹ wa; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Gbogbo opin aiye ti ri igbalà Ọlọrun wa.

Adura lẹhin Komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifúnni, gẹgẹbi Olugbala araiye ti ipa ibí rẹ t'ọjọ́ oni yi ti fun wa li ibí mimọ́ bẹni ki o lè fun wa li iye ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

OJỌ ỌDUN MIMỌ TI STEFANU MIMỌ

Martiri ekini tabi ẹnit'o kọ kú nitori igbagbọ́ Jesu-Kristi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Awọn ọmọ-alade joko lori itẹ idajọ wọn, nwọn sì nsọ̀rọ̀ si mi; awọn enia buburu ṣe inunibini si mi; ran mi l'ọwọ́, Oluwa Ọlọrun mi, nitoriti iranṣẹ rẹ ti pa ofin rẹ mọ́ nigba gbogbo *Ps.* Alabukún fun ni

awọn ẹniti, npa ara wọn mọ lailabawọn ẹṣẹ l'ọna Ọlọrun, ti o si nrin ninu ofin Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, ti ore-ọfẹ fun wa lati mâ ṣe afarawé Ẹnia-Mimọ ti a nbọlá fun l'oni ati lati mâ kẹkọ nipa apẹrẹ rẹ lati fẹ awọn ọtá wa, bi a ti nṣe ọdún ibi ẹniti o sipẹ fun awọn onimmnibini rẹ lodọ Oluwa wa Jesu-Kristi, ẹnit'O jẹ Ọlọrun, t'O wà, t'O si joba pẹlu Iwọ, ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (Iṣe awọn apost. 6-7).

Li ojọ wọnyi ni Stefanu, t'o kún fun ore-ọfẹ ati fun agbara, se iṣẹ iyanu ati iṣẹ aṣẹ nla lârin awọn enia. Nigbanâ ni awọn ẹnikan ninu ẹgbẹ t'a npè ni ti awọn Omnira ati ti ará Kirene, ati ti ará Aleksandria ati ninu awọn ará Sélisia ati ti Asia dide si Stefanu, nwọn si mbá a jiyàn. Ṣugbọn nwọn kò lè kojujasi ọgbọn ati emi t'o nti ipa ẹnu rẹ, sọrọ. Nigbati nwọn gbọ nkan wọnyi nwọn gbà ọgbẹ de inu, nwọn si pahin si i keke, ṣugbọn Stefanu t'o kún fun Ẹmi-Mimọ tejumọ ọrun, o si ri ogo Ọlọrun, ati Jesu t'o nduro l'ọwọ ọtún Ọlọrun, o si wipe : wò o, mo ri ọrun, o ṣi silẹ, ati Ọmọ-Enia nduro l'ọwọ ọtún. Nigbanâ ni nwọn kigbe soke l'ohùn rara, nwọn si dì eti wọn, nwọn fi ọkàn kan ró lù u. Lẹhin igbati nwọn si ti wọ ọ sẹhin ode ilú nâ, nwọn sọ

okuta lù u pa : awọn ẹlẹri sì fi aṣọ wọn lelẹ lẹba ẹṣẹ ọmọkọnri kan t'a npè ni Saulu. Niwọn igbati nwọn nsọ okuta lù Stefanu, o nkigbe pè Oluwa, o sì nwipe : Oluwa Jesu, gbà ẹmí mi. Lẹhinnâ o kunlẹ, o sì kigbe li ohùn rara pe : Oluwa, máṣe kà ẹṣẹ yi si wọn l'ọrun. Lẹhin ọrọ wọnyi o sùn ninu Oluwa.

Graduali. Awọn, ọmọ alade joko l'ori itẹ idajọ wọn, nwọn sì nsọrọ si mi ; awọn enia luburu sì ṣe inunibini si mi. Ran mi l'ọwọ́, Oluwa Ọlọrun mi, k'o sì gbà mi là nipa ànu rẹ. Alleluia, alleluia. Wò o, mo ri ọrun, o ṣi silẹ, ati Jesu nduro l'ọwọ́ ọtún Ọlọrun. Alleluia.

Ihin rere (Mat. 23).

Nigbanà ni Jesu wi fun awọn akowe ati Farisi : E kiyesi i : Emi ran awọn Woli, ati amoye enia, ati akowe si nyin. Awọn ẹnikan ninu wọn li ẹnyin o pa, ti ẹnyin o sì kàn mọ́ agbelebu ; ati omiran ninu wọn li ẹnyin o nà nipaṣan n'ile-apejọ nyin, ti ẹnyin o sì ṣe inunibini si lati ilú de ilú, ki gbogbo ẹjẹ awọn olododo, ti a ti ta silẹ li aiye ki o ba lè wá sori nyin, lati ìgba ẹjẹ Abẹli olôtọ wá ti de ẹjẹ Sakaria, ọmọ Barakia, ẹniti ẹnyin pa làrin tempeli (ile Ọlọrun) ati altari. Lôtọ ni mo wi fun nyin : Gbogbo nkan wọnyi ni yio wá sori iran yi, Jerusalemu, Jerusalemu, iwọ ti o pa awọn Woli, ti o sì sọ okuta lù awọn ti a rán si ọ pa, nigba melo ni emi nfẹ́ ràdọbò awọn ọmọ rẹ bi agbebọ̀-adiẹ ti ràdọbò awọn ọmọ rẹ labẹ apa rẹ, ṣugbọn iwọ kò fẹ́? Láwò o, ao

ti ile nyin silẹ fun nyin li ahoro. Nitori mo wí fun nyin : lati isisiyi lọ ni ẹnyin kì yio ri mi mọ́ titi ẹnyin o fi wipe : ibukún ni fun ẹniti mbọ̀ li orukọ Oluwa !

Ifitọrẹ Awọn apostoli ti yàn Stefanu si oyè ekeji saserdoti, ọkọnri t'o kún fun igbagbọ́ ati fun Ẹmi-Mimọ́, ẹniti awọn Ju sọ okuta lù pa nigbati o nkigbe pè Oluwa, ti o sì nwipe : Oluwa Jesu, gbà ẹmi mi. Alleluia.

Adura ti a hà jẹjẹ.

Oluwa, fi ojurere gbà ọrẹ ti a rù si Ọ li iranti ati ni ọlá awọn enia mimọ́ rẹ, pe bi nwọn ti ti ipa ijiyà wọn dì ológo, bẹ̀gẹgẹ ki awa lè ti ipa ifọkànsìn wa dì alailẹṣẹ nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Mo ri ọrun, o ṣí silẹ, ati Jesu nduro l'ọwọ́ ọtún Ọlọrun. Oluwa Jesu, gbà ẹmi mi, má sì ṣe kà èṣẹ yi si wọn l'ọrun.

Adura. lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki sakramenti mimọ́ t'a ti gbà, k'o lè ma ran wa l'ọwọ́, k'o sì lè ti ipa èbẹ Stefanu mimọ́, akọjẹri-kú dâbobo wa titi lai ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN TI JOHANU MIMỌ APOSTOLI ATI EFANGẸLISTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Lârin awujọ ijọ awọn enia ni Oluwa ti là a l'ẹnu, t'o sì kún u fun ẹmi ọgbọ́n ati oyé; t'o sì wọ ọ l'aṣọ ogo; ati lati kọrin si orukọ rẹ, Iwọ Ọga-ogo. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa oninu rere, fiyesi i lati fi imọlẹ rẹ fun ijọ awọn enia rẹ pe, ni riri imọlẹ gbà, nipa ẹkọ́ ti Johanu mimọ́, apostoli ati akọwe Ihin rere rẹ, ki nwọn ki o lè de ibi iyè ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iwe ọgbọ́n, 15).

Ẹnit'o bẹ̀ru Ọlọrun yio ṣe rere, ẹnit'o sì di ododo mu ṣinṣin yio ri ọgbọ́n, ti yio pade rẹ̀ bi iyàle; on yio fi akara iyè ati oyé bọ ọ, yio sì fun u l'omi ọgbọ́n t'o ni igbalà mu. On yio fi ẹṣẹ mulẹ ninu rẹ̀, yio sì sọ ọ di alailẹ̀yé. On yio mu u dani giri, oju kì yio sì tì i; on yio gbe e ga s'oke, lârin awọn aladugbo rẹ̀. Lârin awujọ ni on yio là a l'ẹnu, ti yio sì kún u fun ẹmi ọgbọ́n ati oyé, ti yio sì wọ ọ l'aṣọ ogo. Iṣura ayọ̀ ati inudidùn ni on yio kójọpọ̀ lori rẹ̀; orukọ ti kì o kú lailai ni Oluwa Ọlọrun wa yio sì fifun u li ijogun.

Graduali. Lârin awọn arakọnri ni ọ̀rọ yi tàn kalẹ kiri pe, ọmọ-ẹhin ni kì yio kú; ṣugbọn Jesu kò wi pe: on kì yio kú. Ṣugbọn emi

fẹ́ ki o duro bẹ̀ titi emi o fi de, iwọ sá mà tọ̀ mi lẹhin Alleluia, alleluia. Eyi li ọmọ-ẹhin nà, ẹniti o jẹri nkan wọnyi, awa sì mọ̀ pe otitọ li ẹrí rẹ̀.

Ihin rere (Joh. 21).

Nigbanâ ni Jesu wí fun Piteru pe: Mà tọ̀ mi lẹhin. Piteru sì yipada, o ri ọmọ-ẹhin ni, ẹniti Jesu fẹ́, mbọ̀ lẹhin, ẹniti o fi ori tì I li òkan-àiya nigba onjẹ alẹ́, ti o sì wi fun U pe: Oluwa tali ẹniti yio fi Ọ hàn? Nigbati Piteru ri i, o wi fun Jesu pe: Oluwa, kini eleyi yio dà? Jesu wi fun u pe: Emi fẹ́ ki o duro bẹ̀ titi emi o fi de. Kini eyini fun ọ? Iwọ sá tọ̀ mi lẹhin. Nitorinà ni ọrọ yi tàn kalẹ kiri ninu awọn arakọnrin, pe ọmọ-ẹhin ni ki yio kú Sugbọn Jesu kò wi fun u pe: On ki yio kú, sugbọn: Emi fẹ́ ki o duro bẹ̀ titi emi o fi de, kini eyini fun ọ? Eyi ni ọmọ-ẹhin nà, ẹniti o jẹri nkan wọnyi, awa sì mọ̀ pe otitọ li ẹrí rẹ̀.

Ifitọrẹ. Olododo yio gbà lẹ bi igi ọpẹ, yio sì dàgba bi igi opépe Libanoni.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi ojurere gbà ẹbọ ti a rù si Ọ li ọjọ́ ọdún mimọ́ ti ọmọ-ẹhin rẹ, nipa ẹbẹ ẹniti awa nreti pe ao gbà wa kuro ninu ẹ̀ṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. O ri bakannâ bi ti Graduali, titi de: Iwọ sá tọ̀ mi lẹhin.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Ọlọrun wa, awa ti a fi onjẹ ati ohun mimu atọrun wá bọ nfi irẹlẹ bẹbẹ l'ọdọ rẹ, li iranti ẹni t'a ti gbà onjẹ mimọ yi k'a lè tipa ẹbẹ rẹ dâbobo wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ T'O TẸLẸ IBÍ J.-K.

Ipilẹṣẹ ti misa. Ọlọrun, nigbati gbogbo dakẹ rọrọ ti oru sì wà l'ọganjọ, nigbanâ ni Ọrọ rẹ Olodumare sọkalẹ lat'ọrun, lati itẹ ọba wá si aiye. *Ps.* Oluwa jọba, ogo ni O wọ l'aṣọ, agbara ni Oluwa wọ l'aṣọ, o sì dì ihamọra. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye; ṣe akoso gbogbo iṣẹ rere jade l'ọpọlọpọ l'orukọ ati nipa itoye Ọmọ rẹ olufẹ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ, etc.

Epistoli (Gal. 4).

Ẹnyin ará mi, nìwọn igbati arôle ba wà li ewe, kò yatọ si ọmọ-ọdọ, bi on tilẹ jẹ Oluwa nkan gbogbo, ṣugbọn o wà labẹ olukọ ati olutọju titi ti di akokò ti baba ti dá. Bẹgẹgẹ sì li awa, nigbati awa ti wà li ewe, awa ti jẹ ọsin labẹ ofin ati ẹkọ atètekọni ti aiye, ṣugbọn nigbati akokò kikún nâ de, Ọlọrun rán Ọmọ rẹ, ẹniti a bí ninu obiri, ti o sì tẹriba fun ofin,

lati dá awọn ti o wà labẹ ofin nìde ati lati sọ wa di ọmọ nipa isọdọmọ. Ati nitoriti ẹnyin nṣe ọmọ, Ọlọrun ti rán Ẹmi Ọmọ rẹ wá si nyin li ọkàn, ti nkigbe wipe: Abba, Baba. Nitorinà kòsi ẹnikan ninu nyin ti nṣe ọmọ-ọdọ mọ́, bikoṣe ọmọ; ati bi o ba ṣe ọmọ, o jẹ aròle pẹlu nipa òre-ọfẹ Ọlọrun.

Graduali. Iwọ lẹwà jù awọn ọmọ enia lọ. A dà òre-ọfẹ si ọ li ète. Lati inu ọkàn mi ni, òrọ rere jade wá; mo nsọ̀rọ iṣẹ mi fun ọba; ahọn mi dabi kalamu ti akọwe ti o fi iyara kọwe. Alleluia, alleluia (ẹ fi ayọ̀ yìn Ọlọrun). Oluwa jọba, ogo ni o wọ̀ li aṣọ, agbara ni Oluwa wọ̀ li aṣọ, on l'o sì fi di ara rẹ̀ l'amure. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 2).

Nigbanà ni ẹnu yà Josefu ati Maria, iyá Jesu, si nkan wọnyi ti a nwi niti rẹ̀. Simeoni sì bukún fun wọn, o sì wi fun Maria, iyá rẹ̀ pe: Kiyesi i, ọmọ yi li a gbé kalẹ fun iparun ati fun ajinde ọ̀pọ̀ enia ni Israeli ati bi àmi isọ̀rọ̀ òdisi. Idà yio sì gún iwọ nà li ọkàn, ki a lè fi ironu ọ̀pọ̀ ọkàn hàn. Ẹnikan sì mbẹ, Anna woli, ọmọbiri Fanueli, li ẹya Aseri, ti o darúgbo pupọ̀pupọ̀; o ti bá ọkọ rẹ̀ gbé li ọdún meje lati ìgba wundia rẹ̀ wá, o sì jẹ opó iwọn ọdún mẹrin le logorin, ẹniti kò kuro ni tempeli (ile Ọlọrun), o sì nfi àwẹ ati adura sìn Ọlọrun l'ọsán ati l'oru. O sì de ibẹ̀ l'akokò nà pẹlu, o yìn Oluwa, o sì sọ̀rọ̀ rẹ̀ fun gbogbo awọn t'o duro de idandè Israeli. Nigbati nwọn

sì ti ṣe nkan gbogbo tan gẹgẹ bi ofin Oluwa, nwọn pada lọ si Galili, si Nasareti ilú wọn.

Ifitọrẹ. Ọlọrun fi idí aiye mulẹ, ti kì yio lè mì. Lati ìgba atijọ l'a ti fi idí itẹ rẹ kalẹ, Ọlọrun, aiyeraiye ni Iwọ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifun ni, nipa ẹbọ ti a rù si ọlá nla rẹ, ki awa ki a lè ri ôre-ọfẹ ifọkànsìn ati ti alafia ti kò nipẹkun gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Kumunioni. Gbé Ọmọ titun ni ati iyá rẹ, ki o sì lọ si ilú Israeli, nitoriti awọn ti o nwá Ọmọ titun ni lati gbà ẹmi rẹ, ti kú.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa fifun ni, nipa agbara ọ̀rọ ijinlẹ yi, ki a lè wẹ ẹṣẹ wa nù, ki a sì lè mu ifẹ tôtọ ti inu wa ṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN MIMỌ TI IKỌLA JESU-KRISTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. A bí ọmọ kan fun wa; yio gbé àmi ijọba rẹ l'ori ejika rẹ, ao ma pè orukọ rẹ ni Angẹli igbimọ nla. *Ps.* Ẹ kọrin titun si Oluwa, nitoriti o ti ṣe ohun iyanu. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, nipa fifi eso fun Maria Wundia alabukún fun ti o mu igbalà ainipẹkun fun araiye, fifuni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki on nâ lè jẹ Alagbawi wa lọdọ rẹ, nipa ẹniti awa ti yẹ lati ri Olufini ni ìye gbà, Oluwa wa Jesu-Kristi Ọmọ rẹ, ẹnit'Ó jẹ Ọlọrun, ti O wà, ti O sì jọba pẹlu Iwọ ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ́, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli.

O ri bakannâ bi ti Misa li oganjọ (wo apá 139).

Graduali. Gbogbo opin aiye ti ri igbalà Ọlọrun wa, Ẹ hó ihó ayọ̀ si Oluwa, gbogbo orilẹ-ede aiye. Oluwa ti sọ igbalà rẹ di mimọ̀, ododo rẹ li o ti fihàn loju awọn keferi.

Alleluia, alleluia. Nigba pupọ̀ ni Ọlọrun tipa awọn Woli bá awọn baba sọ̀rọ nigbani; nikẹhin li ọjọ́ wọnyi O tipasẹ Ọmọ rẹ bá wa sọ̀rọ. Alleluia.

Ihin rere (Luk 2).

Nigbati ijọ́ kejọ pé lati kọ ọmọ nâ nilà, nwọn pè orukọ rẹ ni Jesu, bi a ti sọ ọ tẹlẹ lati ọdọ Angẹli nâ wá ki a tó l'óyun rẹ ninu iyá rẹ.

Ifitọrẹ. Tirẹ ni ọrun on aiye, Iwọ ti fi ipilẹ aiye sọlẹ, pẹlu nkan gbogbo ti o wà ninu rẹ; ododo ati iṣedede ni ipilẹ itẹ rẹ

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ojurere gbà ẹbọ ati adura wa, nipa ọrọ ijinlẹ rẹ mimọ ki iwọ ki o wẹ wa nù, ki o sì fi ânu gbọ ti wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Komunioni. Gbogbo opin aiye ti ri igbalà Ọlọrun wa.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki komunioni yi lè pa ẹṣẹ wa rẹ, ati nipa ẹbẹ Maria Wundia alabukún fun, iyá Ọlọrun k'awa lè jẹ alabapin ninu eso ohun imularada atọrun wá ti awa ti gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Bi ijọ ọsẹ ba bọ s'arin ọdún mimọ ti ikọlà Jesu-Kristi ati ti ifarahàn ti Oluwa fun awọn ọba mẹta, ao kà Misa ijọ ọsẹ t'o tẹle ojọ ti ibi Jesu-Kristi, pẹlu Ihin rere t'o tẹle eyi.

Ihin-rere (Mat. 2).

Nigbati Herodu kú, kiyesi i, Angẹli Oluwa kan yọ si Josefu li oju alá ni Egipti, o wipe: Dide, gbé ọmọ titun ni ati iyá rẹ, ki o sì lọ si ilẹ Israeli, nitoriti awọn ti o nwá ọmọ titun ni lati gbà ẹmi rẹ, ti kú; O sì dide, o mu ọmọ titun nà ati iyá rẹ, o sì wá si ilẹ Israeli ṣugbọn nigbati o gbọ pe Arkelau jọba ni Judea lipò Herodu baba rẹ, o bẹru lati lọ s'ibẹ; bi a sì ti kilọ fun u li oju alá, o pada lọ si ilẹ Galili,

o sì wá joko ni ilú kan ti a npè ni Nasareti, ki òrọ yi ti awọn woli sọtẹlẹ ki o lè ṣẹ pe : Ao pè E ni ará Nasareti.

EPIPHANY

Ifarahàn Oluwa Jesu-Kristi fun awọn Ọba mẹta.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Kiyesii, Oluwa alakoso ilẹ dé; ijọba, agbara ati aṣẹ wà li ọwọ́ rẹ. *Ps.* Ọlọrun, fi idajọ rẹ fun ọba, ati ododo rẹ fun ọmọ ọba. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ t'o fi ọmọ bibí rẹ nikanṣoṣo hàn fun awọn keferi nipa irawọ kan t'o ṣe amọ̀na wọn, nipa ânu rẹ tifuni, ki awa ti o tipa igbagbọ́ mọ Ọ nisisiyi, k'a lè mu wa wá sibi ti a lè ri ogo rẹ li ojukoju ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Is 60).

Dide, Jerusalemu, tàn imọlẹ, nitori imọlẹ rẹ dé, ogo Oluwa sì yọ lara rẹ. Nitori kiyesi i, òkunkun biribiri yio bo aiye mọlẹ, ati òkunkun yio bò awọn orilẹ-ede ; ṣugbọn Oluwa yọ lara rẹ, ao sì ri ogo rẹ̀ lara rẹ. Awọn keferi yio rìn ninu imọlẹ rẹ, ati awọn ọba ninu titàn ti yio yọ lara rẹ Gbé oju rẹ soke, ki o sì wò yika ; gbogbo awọn ti Iwọ ri nṣà ara wọn jọpọ̀,

nwọn wá sọdọ rẹ; awọn ọmọ rẹ ọkọnri yio ti òkere wá, awọn ọmọ rẹ obirin yio dide lẹgbẹ rẹ. Nigbanâ ni iwọ o ri, iwọ yio pọ̀ layọ̀. ẹnu yio ijà ọkàn rẹ, yio sì di nla, nigbati ao yi ọ̀pọ arán erekùsu pada si ọ, ti awọn agba orilẹ-ede yio sì wá sọdọ rẹ. Ọpọ̀lọpọ̀ rakùmi oniké meji yio bò ọ mọlẹ, pẹlu awọn rakùmi oniké kan ti Madiani on Efa; gbogbo nwọn o wá lati Saba, nwọn o mu wura ati turari wá, nwọn yio sì rohin iyìn Oluwa kakiri

Graduali. Gbogbo nwọn o wá lati Saba, nwọn o mu wura ati turari wá, nwọn yio sì rohin iyìn Oluwa kakiri. Dide Jerusalemu, tan imọlẹ, nitori ogo Ọlọrun yọ lara rẹ. Alleluia, alleluia. Awa ti ri irawọ rẹ ni ìha ila ôrun, awa sì wá pẹlu ẹbun lati foribalẹ fun U. Alleluia. (Ẹ fi ayọ̀ yìn Ọlọrun).

Ihin-rere (Mat. 2).

Nigbati a bí Jesu ni Bethlehemu il ẹ̀ya Juda, nigba aiye Herodu ọba, kiyesi i, awọn amoye kan ti ìha ila ôrun wá si Jerusalemu, nwọn mbère wipe: Nibo ni ọba awọn Ju, ti a bí wà? Nitori awa ti ri irawọ rẹ ni ìha ila ôrun, awa sì wá lati foribalẹ fun U. Nigbati Herodu ọba sì ti gbọ́ nkan wọnyi, o tagiri, ati gbogbo awọn arán Jerusalemu pẹlu rẹ. O sì pè gbogbo awọn olori awọn alufa ati awọn akọwe enia jọ, o sì bi wọn lère pe: nibo li ao gbé bí Kristi. Nwọn sì wi fun u pe: ni Bethlehemu li ẹ̀ya Juda, bi a ti kọwe rẹ̀ lati ọwọ́ woli ni wá: Ati iwọ, Bethlehemu, ilẹ Juda, iwọ kì işe kekere julọ

ninu awọn ilu alade Juda, nitori lati inu rẹ ni Balẹ yio jade, ti yio jọba lori Israeli awọn enia mi. Nigbanà ni Herodu pè awọn amoye nâ si ikọkọ. o si bi wọn lẹsọlẹsọ li akoko igbati irawọ nâ hàn fun wọn, o si rán wọn lọ si Bethlehemu, o wipe : Ẹ lọ k'ẹ si wá ọmọ titun nâ li awari, nigbati enyin ba si ri I, ẹ pada wá sọ fun mi, ki emi ki o lè wá foribalẹ fun U pẹlu. Nigbati nwọn gbọ ọrọ ti ọba yi, nwọn lọ; kiyesi i, irawọ ti nwọn ti ri lati ìha ila ôrùn wá, o ṣaju wọn titi o fi wá duro loke ibi ti ọmọ titún nâ gbé wà. Nigbati nwọn si ri irawọ nâ, nwọn yọ ayọ nlanla; nwọn si wọle, nwọn ri ọmọ titún nâ pẹlu iyá rẹ, nwọn wolẹ, nwọn si foribalẹ fun U. Lẹhinnà nwọn tú iṣura wọn, nwọn si ta A lọrẹ wura, turari ati ojia. Bi a si ti kilọ fun wọn li oju alá pe, ki nwọn kì o máṣe pada tọ Herodu lọ mọ, nwọn gbà ọna omiran lọ si ilú wọn.

Ifitọrẹ. Awọn ọba Tarsisi ati ti awọn erekùsu yio ta a lọrẹ ; awọn ọba Arabia ati ti Saba yio mu ẹbun fun u wá ; gbogbo awọn ọba ilẹ aiye ni yio foribalẹ fun U, gbogbo orilẹ-ede ni yio mâ sìn I.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodo rẹ, ti ojurere wò awọn ọrẹ ijọ awọn enia rẹ, ninu eyiti nwọn kò fi wura, turari ati ojia tọrẹ fun Ọ, ṣugbọn ohun ti awọn ẹbun nâ ṣe awọran rẹ, eyi ni, Jesu-Kristi Ọmọ rẹ Oluwa wa, eniti o rù ara rẹ lẹbọ, ti o si fi ara rẹ fun wa : Ẹnit'O jẹ Ọlọ-

run, t'O wà, t'O sì jọba pẹlu Iwọ ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Komunioni. Awa ri irawọ rẹ ni iha ila òrun, awa sì wá pẹlu ẹbun lati foribalẹ fun U.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, fifuni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki ohun ti awa ti ifọkànsìn didakẹjẹ ṣe ọdún rẹ, k'awa lè fi oyé ọkàn mimọ mọ Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ EKINI LẸHIN IFARAHAN OLUWA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Mo ri ọkonri kan njoko lori itẹ giga, ẹniti opọlopọ Angẹli nforibalẹ fun, ti nwọn sì nfi ọkàn kan korin wipe: Ẹ wò ẹniti ijọba rẹ duro lai ati lailai. *Ps.* Ẹ hó ihó ayọ si Ọlọrun, ẹnyin gbogbo ilẹ aiye; ẹ fi ayọ sìn Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ti ojurere gbà adura ati ẹbẹ awọn enia rẹ, ki o sì da ibukún rẹ sori wọn, ki nwọn ki o lè mà mọ ohun ti nwọn iba mà ṣe, ki nwọn ki o sì lè ni agbara lati ṣe eyiti nwọn ti mọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. 12).

Ẹnyin ará mi : mo ti ânu Ọlọrun bẹ nyin, ki ẹnyin rù ara nyin lẹbọ âye, mimọ́ ati itẹwọgba si Ọlọrun, ki isìn nyin lè jána. Ẹ ma sì ṣe afarawe aiye, ṣugbọn ki ẹnyin parada nipa siso ẹmi nyin d'ọtún, ki ẹnyin ki o lè mọ kini Ọlọrun fẹ, kil'o dara, kil'o jẹ itẹwọgba l'oju rẹ, kil'o sì jẹ pipé. Nitori mo wi fun gbogbo awọn ti o wà ninu nyin, nipa agbara ôre-ọfẹ t'a ti fi fun mi pe, k'ẹnyin k'o máṣe gbé ara nyin ga ni ìro nyin jù bi o ti yẹ lọ, ṣugbọn ki ẹnyin ki o ro ti ara nyin niwọntunwọnsi gẹgẹ bi ọṣuwọn igbagbọ́ ti Ọlọrun ti fifun olukuluku nyin. Nitori gẹgẹ bi awa ti li èya pupọ li ara kan, ti gbogbo èya kò sì ni iṣẹ kannâ, bẹ́gẹgẹ bì awa tilẹ jẹ pupọ, sibẹsibẹ a ṣe ara kan ninu Kristi sì ṣe èya ara ọmọnikeji rẹ̀ : ninu Kristi-Jesu Oluwa wa.

Graduali. Ibukún ni fun Oluwa, Ọlọrun Israeli, ẹnikanṣoṣo ti nṣe olùn iyanu nla lati igba aiyeraiye wá. Oluwa, jẹ ki awọn òke nla ki o ri alafia gbà fun awọn enia rẹ, ati awọn òke kekere ododo, Alleluia, alleluia. Ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun, ẹnyin ilẹ aiye gbogbo, ẹ fi ayọ̀ sìn Oluwa. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 2).

Nigbati Jesu di ọmọ ọdún mejila, awọn ôbi rẹ̀ gòke lọ si Jerusalemu, gẹgẹbi iṣe wọn, li akokò ọdún irekọja. Nigbati awọn ọjọ́ ọdún nâ sì pari, nwọn pada bọ̀ ; ṣugbọn ọmọ nà

Jesu duro ni Jerusalemu ; awọn ôbí rẹ̀ kò sì mọ̀. Ṣugbọn nwọn ṣebi o wà ninu ẹgbẹ̀ èro, nwọn rìn irin ọjọ́ kan, nwọn sì wá a kiri ninu awọn ará ati awọn ojulumọ̀ wọn. Bi nwọn kò sì ti ri i, nwọn tún pada lọ si Jerusalemu lati wá a kiri. O sì ṣe li ijọ́ kẹta nwọn rí i ninu tempeli (ile Olọrun), o joko lârin awọn olukọni, on gbọ́ ti wọn, o sì mbi wọn lêre. Gbogbo awọn ti o gbọ́ ọrọ rẹ̀ ni ẹnu sì ya si oyé ati idahún rẹ̀, Nigbati nwọn sì ri i, ẹnu ya wọn, iyá rẹ̀ sì wi fun u pe : Ọmọ, èṣe ti Iwo fi ṣe bẹ̀ sì wa? Sawò, baba rẹ ati emi ti nfi ibanujẹ wá ọ kiri. O sì dahùn wi fun wọn pe : Èṣe ti ẹnyin fi nwá mi kiri? Ẹnyin kò ha mọ̀ pe emi kò lè máṣaiṣe iṣẹ Baba mi? Ṣugbọn ọrọ ti o sọ kò yé wọn. O sì bá wọn sọkalẹ lọ si Nasareti, o sì tẹriba fun wọn. Iyá rẹ̀ si pa gbogbo ọrọ wọnyi mọ́ ninu ọkàn rẹ̀. Jesu sì nlọ s'iwaju li ọgbọ́n, li ọdún ati li ôre-ọfẹ niwaju Olọrun ati enia.

Ifitọrẹ. Ẹ hó ihó ayọ̀ si Olọrun, ẹnyin orilẹ-ede aiye, ẹ fi ayọ̀ sìn Oluwa; ẹ fi ikanju ati inu didun wá lati foribalẹ fun u, nitoriti Oluwa li Olọrun.

Adura t'a kà jeje.

Oluwa, jẹ ki ẹbọ t'a rù si Ọ, sọ wa di alâye, k'o sì mu wa l'agbara nigbagbogbo ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ọmọ mi èṣe t'iwọ fi ṣe bẹ̀, si wa? Emi ati baba rẹ ti nfi ibanujẹ wá ọ kiri. Eṣe ti ẹnyin fi nwá mi kiri? Ẹnyin kò ha mọ̀ pe, Emi kò lè má ṣai ṣe iṣẹ Baba mi?

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa nfi irẹlẹ bẹbẹ f'ọdọ rẹ, nipa ânu rẹ, fi funni, ki awa ti Iwọ fi awọn sakramenti rẹ bọ, k'a lè fi ihùwa itẹwọgba sìn Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ EKEJI LẸHIN IFARAHAN OLUWA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ọlọrun, jẹ ki gbogbo aiye ki o ma foribalẹ fun Ọ, k'o ma kọrin yìn Ọ; k'o sì ma kọ orin si orukọ rẹ Iwọ ọga ogo. *Ps.* Ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun, gbogbo ẹnyin ilẹ aiye, ẹ kọrin iyìn si orukọ rẹ, ẹ fi ogo fun ọlá rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ t'o nṣe akoso ọrun on aiye, fi ânu gbọ́ ẹbẹ awọn enia rẹ, ki o sì fi alafia rẹ fun wa ni gbogbo ọjọ́ aiye wa, nipasẹ Oluwa wa Jesu-Kristi. Amin.

Epistoli (Rom. 12).

Ẹnyin ará mi, gẹgẹbi ôre-ọfẹ ti a fifun wa, awa ri onirûru ẹbun gbà. Ki ẹniti o ri ẹbun isọtẹlẹ gbà ki o lò o gẹgẹbi osuwọn igbagbọ́; ki ẹniti a pè si iṣẹ isìn Ọlọrun ki o mâ duro ti iṣẹ nâ; ki ẹniti o ri ẹbun atikọ́ni gbà, ki o mâ fi ọkàn si kikọ́; ki ẹniti o ri ẹbun atigbà ni

niyanjú gbà ki o mâ fi itara gbà ọmọnikeji rẹ niyanjú ; ki ẹniti o ṣe ôre ânu, ki o mâ ti inu kan ati laisi aṣehán ṣe e ; ki ẹniti o ṣe olori fun ẹnikeji rẹ, ki o mà ṣe e li oju mejeji ; ki ẹniti o ṣe iṣẹ ânu, ki o mâ fi tayọtayọ ṣe e ; ki ifẹni nyin ki o wà li aiṣètan. Ẹ korira ohun buburu, ẹ faramọ ohun rere. Ẹ mâ fi ifẹ ará fẹ ara nyin ; ẹ máṣe ṣe imẹlẹ ni iṣẹ ṣiṣe nyin ; ẹ mâ jẹ onitara gbigbona li ọkàn ; ẹ mâ ranti pe Oluwa li ẹnyin sìn ; ẹ mâ yọ ni ireti nyin, ẹ mâ mu sûru ninu ipọnju, ẹ mâ fi irọju gbadua ; ẹ mâ ran awọn enia mimọ lọwọ ninu aini wọn, ẹ fi ara nyin fun alejò ṣiṣe. Ẹ mâ bukúnfun awọn ti nṣe inunibini si nyin ; ẹ mà sùre fun wọn, ẹ má sì ṣe fi wọn ṣepè. Ẹ mâ yọ pẹlu awọn ti nyọ ; ẹ mâ sọkun pẹlu awọn ti nsọkun ; ẹ mâ wà ni inu kannà si ara nyin ; ẹ máṣe nàgasi ohun ti o ga, ṣugbọn ki ohun ti o ni irẹlẹ, ti kò sì niyìn ki o kún nyin loju.

Graduali Oluwa rán ọrọ rẹ jade, o sì mu wọn larada, o sì gbà wọn kuro ninu ikú. Ki nwọn ki o ṣọpẹ fun Olọrun nitori ânu rẹ, ki nwọn ki o sì yìn I nitori iṣẹ iyanu rẹ si awọn ọmọ enia.

Alleluia, alleluia (ẹ mâ fi ayọ yìn Olọrun). Ẹ fi iyìn fun Oluwa, gbogbo ẹnyin Angeli rẹ. ẹ fi iyìn fun U, gbogbo ẹnyin ọmọ-ogun rẹ. Alleluia.

Ihin rere (Joh. 2).

Nigbanà ni a nṣe igbeyawo kan ni Kana ti Galili, iyá Jesu sì mbẹ nibẹ. A sì pè Jesu ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ si ibi igbeyawo pẹlu. Nig-

bati ọti vini tán, iyá Jesu wí fun U pe : Nwọn kò ni ọti vini. Jesu sì wí fun u pe : Obirin, kini eyi sì mi ati iwọ? Wakati mi kò ti dé. Iyá rẹ sì wi fun awọn iranṣẹ pe ! Ohunkohun ti o ba wí fun nyin, ẹ ṣe e. Ikoko omi sì mbẹ nibẹ ti a pèse silẹ fun iwẹnu awọn Ju, ọkọkan wọn gbà to iwọn ladugbo meji tabi mẹta. Jesu wi fun wọn pe ; ẹ fi omi kún ìkoko wọnyi. Nwọn sì kún wọn titide eti. Jesu sì wí fun wọn pe : Ẹ bù u jade nisisiyi, ki ẹ sì gbé e lọ fun olori asè. Nwọn sì gbé ẹ lọ. Ṣugbọn nigbati olori asè tọ omi ti a sọ di ọti vini wò, ti kò sì mọ ibiti o ti wá (bikoṣe awọn iranṣẹ ti o pọn omi nâ wá li o mọ), o pè ọkọ iyawo, o sì wi fun u pe : Olukuluku enia li atètekọṣe amâ gbé ọti vini rere kalẹ, nigbati awọn enia ba sì mu yó tán, nigbanâ ni a gbé eyi ti kò dara bayi kalẹ, ṣugbọn iwọ pa ọti vini rere mọ titi o fi dì isisiyi. Eyi ni iṣẹ iyanu ekini, ti Jesu ṣe ni Kana ti Galili, o sì fi ogo rẹ hàn jade ; awọn ọmọ-ẹhin rẹ sì gbà a gbọ.

Ifitọrẹ. Ẹ hó ihó ayọ si Ọlọrun, gbogbo ẹnyin itẹ aiye ; ẹ kọrin iyìn si orukọ rẹ. Ẹ wá gbọ, gbogbo ẹnyin ti o bẹru Ọlọrun, emi o sì rohin ohun nla ti Oluwa ṣe fun ọkàn mi. Alleluia.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, ṣọ ọrẹ ti a rù si Ọ lẹbọ dì mimọ, ki o sì wẹ wa nu kuro ninu abawọn ẹṣẹ wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa wi fun wọn pe : Ẹ fi omi kún ìkoko wọnyi, ki ẹ sì gbé wọn lọ fun

olori asè. Nigbati olori asè tọ omi ti a sọ di ọti vini wò, o wí fun ọkọ iyawo pe : iwọ pa ọti vini rere mọ titi o fi di isisiyi. Eyi ni iṣẹ iyanu ekini ti Jesu ṣe loju awọn ọmọ-ẹhin rẹ.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki eso iṣẹ agbara rẹ ki o mâ bisi i ninu wa, ki awọn sakramenti rẹ mimọ, ti o fun wa lagbara, ki o lè mu wa mura nipa ôreọfẹ rẹ lati ri awọn ileri wọn gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN ORUKỌ MIMỌ JULỌ TI JESU-KRISTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Li orukọ Jesu ni ki gbogbo èkun ki o mâ kunlẹ li ọrun, li aiye ati li ọrun-apâdi, ki gbogbo ahọn ki o sì mâ jẹwọ pe Oluwa Jesu-Kristi mbẹ li ogo Ọlọrun Baba. *Ps.* Oluwa, Ọlọrun wa, bi orukọ rẹ ti niyìn to ni gbogbo ilẹ aiye ! Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o fi Ọmọ bibì rẹ nikanṣoṣo ṣe Olugbala araiye, ti o sì fẹ k'a mâ pè orukọ rẹ ni Jesu, nipa ânu rẹ fifun ni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, bi awa ti mbọlátun orukọ rẹ mimọ li aiye yi, k'awa lè l'alafia lati mâ ri oju rẹ titilai li ọrun rere ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ise apost. 4).

L'ojó wonyi ni Piteru, t'o kún fun Emi-Mimó, wipe. E gbó t'emi, enyin olori awon enia ati enyin alàgba, bi o ba se pe a da wa l'ejo l'oni nitori òre ti a se fun okonri alarun, ti enyin sì fé mò bi a ti mu u l'ara dá, mo wi fun gbogbo nyin ati gbogbo enia Israeli pe, li oruko Jesu-Kristi ti Nasareti, ti enyin kàn mó agbelebu, ti Olorun gbé dide kuro ninu okú, ni a mu okonri yi t'o duro niwaju nyin nisisiyi l'ara dá. Jesu nâ li okuta ti enyin. amole, kò sile, ti o sì di pataki igun ile. Béni kò sì si igbalà l'odo elomiran, nitori kò si oruko miran labe orun ti a fi fun awon enia, ti a lè fi gbà wa là.

Graduali. Oluwa Olorun wa, gbà wa là, ki o sì gbà wa là kuro ninu awon orilè-ede, ki awa lè yìn oruko re mimó l'ogo, ki awa sì lè sogo ninu iyìn re. Iwo, Oluwa, ni Baba ati Olurapada wa, lati aiyeraiye ni oruko re.

Alleluia, alleluia. Enu mi yio ma sòro iyìn Oluwa ti gbogbo awon enia ki o ma sì fi ibukún fun oruko rè mimó. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 2).

Nigbati ijó keta pé lati ko omo nâ nila, nwon pè oruko rè ni Jesu, bi a ti so o tele lati odo Angeli nâ wá ki a to loyún rè ninu iyá rè.

Ifitore. Oluwa, Olorun mi, tokàntokàn li emi o sope fun O; emi o sì mâ yìn Oruko re

logo titilai, nitori oninu tùtu ati oninu rere li Iwọ, Oluwa, Iwọ sì pọ̀ li ânu fun gbogbo awọn ti nkigbe pè orukọ rẹ. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Ọlọrun ânu, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ibukún rẹ, ti o pa gbogbo awọn ẹdá rẹ mọ́ ti o sì sọ wọn dì alâye, ki o sọ ẹbọ yi ti a rù si Ọ li ogo orukọ ọmọ rẹ Oluwa wa Jesu-Kristi dì mimọ́, ki o lè jẹ itẹwọgbà fun Ọlà nla rẹ, ki o sì lè ṣe anfani fun igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Kommunioni. Oluwa, gbogbo awọn orilẹ-ede, ti Iwọ dá, ni yio wá lati mà foribalẹ fun Ọ ati lati mâ yìn orukọ rẹ logo, nitori titobi ni Iwọ, Iwọ sì nṣe ohun iyanu; Iwọ nikan li Ọlọrun. Alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olọ́dùmare ati aiyeraiye, Iwọ ti o dá wa, ti o sì gbà wa là, fi ojurere gbọ́ ẹbẹ wa, ki o sì fiyesii lati fi ânu ati ojurere gbà ẹbọ ọdọ-agutan si igbalà, ti awa rù si Ọlá nla rẹ li Ọlá orukọ ọmọ rẹ, Oluwa wa Jesu-Kristi; nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ, labẹ âbo orukọ ologo ti Jesu, k'awa lè yọ̀ nitoriti a ti kọ́ orukọ wa sinu iwé awọn ayantẹlẹ ataiyeraiyewá li ọrun rere; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸTA LẸHIN IFARAHAN

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ ma foribalẹ fun Ọlọrun, gbogbo ẹnyin Angẹli rẹ : Sioni ti gbọ́, inu rẹ̀ sì dùn ; awọn ọmọbiri Juda sì nyọ̀. *Ps.* Oluwa jọba, ki aiye ki o yọ̀ ; ki inu ọpọlọpọ erekusu ki o dùn. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, fi ojurere wò ailera wa ; ki o si nà ọwọ́ ọtún Ọlá nla rẹ jade lati dâbobo wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. 12).

Ẹnyin ará mi, ẹ má ṣe kà ara nyin si bi amoyẹ. Ẹ má ṣe fi buburu gbẹsan buburu fun enikẹni. Ẹ tẹra mọ́ iṣẹ rere, ki iṣe iwaju Ọlọrun nikan, ṣugbọn niwaju gbogbo awọn enia pẹlu. Ẹ ma fi alafia ba gbogbo awọn enia gbé bi ẹ̀ lè ṣe, n'iwọn bi ẹ̀ sì ti lè ṣe to. Ẹ má ṣe gbẹsan fun ara nyin, ẹnyin ará mi olufẹ́ ; ṣugbọn ẹ fi àye silẹ fun ibinu Ọlọrun, nitori a ti kọwe rẹ̀ pe ẹsan ni ti Emi, Emi o gbẹsan, ni Oluwa wi. Nitorinà bi ebi ba npa ọtá rẹ̀, fun u l'onjẹ : bi ongbẹ ba ngbẹ ẹ̀, fun u l'ohun mimu ; nitori ni ṣiṣe bẹ̀ ; Iwọ o kó ogunná jọ si i l'ori. Máṣe jẹ ki buburu ṣẹgun rẹ̀, ṣugbọn fi rere ṣẹgun buburu.

Graduali. Oluwa, awọn keferi yio ma bẹru orukọ rẹ̀, gbogbo awọn ọba aiye yio si ma bọla

fun ogo rẹ. Nitori Oluwa ti tún Sioni kọ́, yio sì farahàn ninu ogo rẹ̀ n'ibẹ̀. Alleluia, alleluia. Oluwa jọba. Ki aiye ki o yọ̀, ki inu ọpọ̀lọpọ̀ erekusu ki o sì dùn. Alleluia.

Ihin rere (Mat. 8).

Nigba kannâ ti Jesu ti ori òke sọkalẹ, opọ̀lọpọ̀ enia ntọ̀ Ọ lẹhin ; kiyesi i, adẹtẹ kan tọ̀ Ọ wá, o nforibalẹ fun U, o sì wi pe : Oluwa, bi Iwọ ba fẹ́, Iwọ lè mu mi larada. Jesu sì nà ọwọ́ rẹ̀, o fi bà a, o sì wipe : Mo fẹ́, ki ara rẹ ki o da ; lojukannâ ẹ̀tẹ rẹ̀ sì san. Jesu sì wi fun u pe : kiyesara rẹ ki o máṣe sọ ọ fun ẹnikan, ṣugbọn mâ lọ fi ara rẹ hàn fun awọn alufa, ki o sì bùn ẹbun ti Moses pa laṣẹ bi àmi-ẹ̀rí fun wọn. Nigbati Jesu sì wọ̀ Kafernaumu, balogun ọrún kan tọ̀ Ọ wá, o mbẹ̀ Ẹ, o sì nwipe : Oluwa, ọmọ-ọdọ̀ mi dubulẹ arùn ẹ̀gba ni ile, irora rẹ̀ sì pọ̀ gidigidi. Jesu sì wí fun u pe : emi mbọ̀ wá mu u larada. Ṣugbọn balogun ọrún nâ dahùn wipe : Oluwa, emi kò yẹ ki Iwọ ki o wọ̀ abẹ orule mi, ṣugbọn sọ kiki ọ̀rọ̀ kan, o sì mu ọmọ-ọdọ̀ mi larada. Nitoriti, ẹniti o wà labẹ̀ oloyè li emi pẹlu, mo sì ni ọmọ-ogun lẹhin mi, nigbati mo sì wí fun ẹnikan pe : lọ, a sì lọ ; ati fun ẹnikeji pe : wá, a sì wá ; ati fun ọmọ-ọdọ̀ mi pe : ṣe eyi, a sì ṣe e. Nigbati Jesu sì gbọ́, ẹnu ya a, O sì wí fun awọn ti o ntọ̀ Ọ lẹhin pe : irú igbagbọ́ nla to bayi li emi kò ri ni Israeli. Mo sì wí fun nyin pe ọpọ̀lọpọ̀ enia ni yio ti ìha ìla ati ìwọ-ôrùn wá, nwọn yio sì bá Abrahamu ati Isaaki ati Jakọbu joko ni ijọba ọrun. Ṣugbọn awọn ọmọ

ijọba li a o sọ sinu òkunkun biribiri, nibẹ ni nwọn o mâ sọkun, ti nwọn o sì ma pa ehín keke. Jesu sìwí fun balogun ọrún nâ pe : ma ba ọna tirẹ lọ, bi Iwọ sì ti gbagbọ, bẹni k'o ri fun ọ, A sì mu ọmọ ọdọ rẹ l'ara dá, ni wakati kannâ.

Ifitọrẹ. Ọwọ ọtún Oluwa ti fi agbara rẹ hàn, ọwọ ọtún Oluwa sì gbé mi ga. Emi kì yio kú, bikoṣe yiyè, emi sì ma rohin iṣẹ O'luwa.

Adura t'a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi fun ni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki ẹbọ yi k'o wẹ wa nù kuro ninu ẹṣẹ wa, k'o sì sọ ọkàn ati ara awọn ọmọ-ọdọ rẹ di mimọ, ki nwọn ki o lè rù ẹbọ nâ si Ọ bi o ti yẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin..

Komunioni. Ẹnu yà gbogbo wọn si ọ̀rọ ti njade l'ẹnu Ọlọrun

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Iwọ ti o fi òre-ọfẹ fun wa lati pín ninu sakramenti rẹ mimọ, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, fiyesi i lati mu wa yẹ lati ri eso rẹ t'o ni ibukún gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi wa Oluwa. Amin.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸRIN LẸHIN IFARAHÀN

Ipilẹṣẹ ti misa, Graduali, Ifitọrẹ ati Komunioni ri bakannâ bi ti misa t'ọjọ ọsẹ ẹkẹta t'o ṣaju eyi.

Adura.

Ọlọrun Iwọ mọ ewu nla t'a fi wa si; Iwọ mọ pe, ailera ẹdá enia yio mu wa ṣubu s'inu rẹ bi Iwọ kò ba wá ran wa lọwọ; nitorinâ fun wa l'agbara l'ọkàn ati l'ara, k'awa lè fi iranlọwọ rẹ bori gbogbo eyi t'awa ni lati jiya nitori ẹṣẹ wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. 13).

Ẹnyin ará mi, ẹ máṣe jẹ ẹnikẹni nigbese ohun kan, bikoṣepe ki olukuluku nyin fẹ ọmọnikeji rẹ; nitori ẹniti o ba fẹ ọmọnikeji rẹ, o kó ofin já. Nitori eyiyi: Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga; Iwọ kò gbọdọ pania; Iwọ kò gbọdọ jale; Iwọ kò gbọdọ jẹri eke, Iwọ kò gbọdọ ṣojukokoro, ati gbogbo ofin miran, li a ti kópọ ninu ọrọ yi pe: Iwọ fẹ ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ. Ifẹ si ọmọnikeji kò ṣe nkan buburu, nitorinâ ifẹ ni akọja ofin.

Ihin rere (Mat. 8).

Nigbanâ ni Jesu bọ si ọkọ, awọn ọmọ-ẹhin rẹ si tẹle e. Si wò o, afẹfẹ nla dide ninu adagun tobẹ ti a fi bò ọkọ mọlẹ ninu riru omi; ṣugbọn on sùn. Awọn ọmọ-ẹhin rẹ si tọ Ọ wá, nwọn

sì jí i, nwọn nwipe : Oluwa, gbà wa là, awa gbé Jesu sì wi fun wọn pe : èṣe ti ẹnyin fi ṣe ojo bẹ, ẹnyin onigbagbọ́ kekere? Nigbanâ ni o dide, o paṣẹ fun afẹfẹ ati adagun lati pàrọrọ, idakẹrọrọ sì de. Ṣugbọn ẹnu yà awọn enia ti o wà nibẹ, nwọn sì wipe: Tani eleyi, ti afẹfẹ ati omi okun gbọ́ tirẹ?

Adura ti a kà jẹjẹ.

Ọlọrun Olodumare, fifun ni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki ẹbọ yi ti a rù si Ọ lè gbà ailara wa kuro ninu gbogbo tulasìn, ki o sì lè mâ fun u lagbara nigbagbogbo; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, fifun ni, ki ẹbun rẹ ki o lè yọ wa kuro ninu afẹ́ t'aiye yi, nipa onjẹ atọrunwá ki o sì lè mu agbara titún wá fun wa nigbagbogbo; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ ẸKARUN LẸHIN IFARAHAN

Ipilẹṣẹ ti misa, Graduali, Ifitọrẹ ati Komunioni ri bakannâ bi ti misa l'ijọ́ ọsẹ ẹkẹta.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, fi iranlọwọ́ titi lọ ti inurere rẹ ṣe itọju awọn ará ile rẹ pe, bi

nwọn ti nfi ara lé kiki ireti ôre ọfẹ rẹ atorunwá nikan, ki âbo rẹ lè ma tì wọn lẹhin nigbagbogbo ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura keji l'adura iranti ti Maria mimọ ; wò ijọ ọsẹ ekini ti adfenti.

Epistoli (Kol. 3).

Enyin arà mi, bi ayanfẹ Olorun, ẹni mimọ ati olufẹ, ẹ mu iyonu ânu wọ, inurere, irẹlẹ, iwa pẹlẹ, sùru. Ẹ ma fi sùru gbà ọmọnikeji nyin, ki olukuluku nyin si ma darijì ẹnikeji rẹ, bi o ba ni ìja si ẹnikan ; bi Oluwa ti ndarijì nyin, bẹgẹgẹ ni k'enyin k'o ma ṣe pẹlu. Ṣugbọn jù gbogbo rẹ lọ, ẹ ni ifẹni, ti ise ânmure iwa pipé. Ẹ jẹ ki alafia Kristi fi ayọ jọba ninu ọkàn nyin, s'inu eyiti a pè nyin pẹlu lati ṣe ara kan ; ki enyin ki o si mà dupẹ nitori ôre-ọfẹ rẹ yi. Ẹ jẹ ki ọrọ Kristi gbé inu nyin li ọpọlọpọ, ki o si kún nyin fun ogbón. Ẹ mâ kọ ara nyin, ki ẹ si mâ gbà ara nyin niyanju pẹlu orin mimọ ati orin iyìn ati orin ẹmí ; ẹ mâ fi idupẹ ati tọkàntọkàn korin si Oluwa. Ohunkohun ti enyin ba nṣe li ọrọ tabi ni iṣe, ẹ mâ ṣe gbogbo rẹ li orukọ Oluwa Jesu-Kristi ; ki ẹ si mâ fi idupẹ fun Olorun Baba nipasẹ rẹ.

Ihin rere (Mat. 13).

Nigbanà ni Jesu pa owe yi fun awọn ọmọẹhin rẹ pe : Ijọba ọrun dabi ọkọnri ti o fọn irugbin rere si oko rẹ. Ṣugbọn nigbati awọn enia sùn, ọtá rẹ wá, o fọn èpo buburu sinu

alikama, o sì bá tirè lọ. Ṣugbọn nigbati èbu rè sọ jade ti o sì seso, èpo buburu farahàn pẹlu. Nigbanà ni awọn ọmọ-ọdọ bàle nà tọ ọ wá, nwọn wi fun u pe : Oluwa, Iwọ kò ha fọn irugbin rere sinu oko rẹ? Nibo ni èpo buburu ti o wà nibè ti wá? O sì wi fun wọn pe : Ọtá mi li o ṣe eyi. Awọn ọmọ-ọdọ rè sì tún bi i lère pe : Iwọ ha fẹ ki awa ki o lọ tú wọn kuro? O sì wipe : Bẹ̀kọ, ki ẹnyin má ba tú alikama pẹlu nigbati ẹnyin ba ntú èpo buburu kuro. Ẹ jẹ ki awọn mejeji ki o dàgba pọ titidi igba ikorè ; ati li akokò ikorè emi o wi fun awọn alakorè pe : Ẹ tètekọ kó èpo buburu jọ, ki ẹ sì dì wọn ni ití lati fi iná jó wọn ; ṣugbọn ẹ kó alikama sinu abà mi.

Adura ti a hà jejẹ.

Oluwa, awa rù ẹbọ ùtutu si Ọ, nipa iyọnu rè, ki Iwọ ki o lè dari èṣẹ wa jì wa, ki o sì lè tọ ọkàn wa ti ntase si ọ̀na ; nipasẹ J.-K. etc.

Adura keji.

Oluwa, igbalà wa, gbọ́ tiwa ; ki Iwọ ki o dàbobo wa l'ọdọ gbogbo awọn ọtá t'ọkàn ati t'ara wa nipa agbara sakramenti, k'o sì fi òre-ọfẹ fun wa ninu aiye yi, ati l'aiye ti mbọ̀, ki o sì jẹ k'awa lè ri ogo rẹ ; nipasẹ J.-K. etc.

Adura lẹhin komunioni.

Olọrun Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fun wa ni eso igbalà, àmi-èrí eyiti awa ti ri gbà ninu sakramenti mimọ́ yi ; nipasẹ J.-K etc.

Adura keji.

Oluwa, awa mbệbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ sakramenti mimọ́ t'a rù si Ọ, ki o sọ wa di mimọ́, ki o sì lè dâbobo wa ati, nipa ẹbẹ Maria Wundia alabukúnfun, ati iyá Ọlọrun ; ti Josefu mimọ́, ti awọn Apostoli rẹ mimọ́, Piteru on Paulu, ati ti gbogbo awọn enia-mimọ́ rẹ, ki o lè wẹ wa nù kuro ninu gbogbo ẹṣẹ wa, ki o sì lè gbà wa là kuro ninu gbogbo ipọnju ; nipasẹ J.-K. etc.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸFA LẸHIN IFARAHÀN OLUWA

Ipilẹṣẹ ti misa, Graduali, Ifitọrẹ ati Komunioni ri bakânnà bi ti misa li ijọ́ ọsẹ ẹkẹta.

Adura.

Ọlọrun Olodumare, awa mbệbẹ lọdọ rẹ fifunni, ki ọkàn wa lè kún fun ìro mimọ́ ati titọ́ nigbagbogbo, li ọ̀rọ ati ni iṣe ki awa sì lè ṣe kiki eyi ti o wù Ọ nikanṣoṣo ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Tess. I).

Ẹnyin ará mi ; awa ndupẹ fun Ọlọrun nigbagbogbo fun gbogbo nyin, awa nṣe iranti nyin ninu adura wa nigbagbogbo ; niwaju Ọlọrun

ti iṣe Baba wa, awa sì nranti iṣẹ igbagbọ́ nyin, iṣẹ ifẹ́ni nyin, ati idurosinsin ireti ti ẹnyin ni sì Oluwa wa Jesu-Kristi ; awa mọ̀, ará olufẹ́ Ọlọrun, bi iyan nyin ti ri : nitori a kò wasu Ihin-rere fun nyin nipa kiki ọ̀rọ nikan, ṣugbọn iṣẹ iyanu, agbara Ẹmi-Mimọ́ ati ọ̀pọ ẹ̀bun rẹ̀ tẹle e pẹlu, bi ẹnyin ti mọ̀ irú enia ti awa jẹ lârin nyin nitori igbalà nyin. Ẹnyin sì di alafarawé wa ati ti Oluwa, bi ẹnyin sì gbà ọ̀rọ nâ lârin ọ̀pọlọpọ ipọnju pẹlu ayọ̀ Ẹmi-Mimọ́ ; tobẹ̀ ti ẹnyin di apẹrẹ fun gbogbo awọn onigbagbọ́ ni Masedonia ati Akaia ; nitoripe nipa nyin li ọ̀rọ Oluwa tàn kalẹ kì iṣe ni kiki Masedonia ati Akaia nikan, ṣugbọn okiki igbagbọ́ nyin si Ọlọrun kàn ká ibi gbogbo, tobẹ̀ ti awa kò ni isọ̀rọ ohunkohun mọ́ ; nitoripe awọn tikala wọn ròhin nipa ti wa irú iwọle ti awa ti ri lọdọ nyin, bi ẹnyin sì ti yipada si Ọlọrun kuro ninu orisa lati mâ sìn Ọlọrun alâye ati otitọ, ati lati ma durode Ọmọ rẹ̀ Jesu lati ọrun wá (Ẹnit'o gbé dide kuro ninu okú), t'o sì gbà wa kuro ninu ibinu ti mbọ̀.

Ihin rere (Mat. 13).

Nigbanâ ni Jesu pa owe yi fun ijọ awọn enia pe : Ijọba ọrun dabi wóro irugbin mustardi kan eyi ti ọkọnri kan ti mu, t'o sì fọn sinu oko rẹ̀. Lõto wóro nâ kere jù gbogbo awọn ewebẹ miran lọ, o sì di igi, tobẹ̀ ti awọn ẹiyẹ oju-ọrun wá gbé ori ẹká rẹ̀. Owe miran li o pa fun wọn pe : Ijọba ọrun dabi iwukara ti obiri kan mu, ti o sì fi sinu osuwọn iyẹfun mẹta, titi gbogbo rẹ̀ fi di wiwu. Gbogbo nkan wọnyi

ni Jesu ti powe fun awọn ijọ enia; kò si sòrọ fun wọn bikose li owe, ki òrọ yi ti a ti ẹnu woli sọ, ki o lè ṣẹ pe: emi o làna mi lati powe; emi o sọ nkan wọnyi jade, ti o farapamọ lati isẹdalẹ aiye wá.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Olorun, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, jẹ ki ẹbọ yi k'o lè wẹ wa nù, ki o si lè sọ wa d'ọtún, kio lè ṣe akoso wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura lẹhin Komunioni.

Oluwa, awa, ti a ti onjẹ didùn atorunwá bọ, mbẹbẹ lodọ rẹ, fifuni, lai ki awa lè ma ṣ'afẹri si ohun t'o fun wa ni iye tôtọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ NI SEPTUAGESIMA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Irora ikú yí mi ká; irora ipò-okú yí mi ká; ṣugbọn ninu ipọnju mi emi kigbe pè Oluwa, O si gb'ohùn mi lati inu ibi mimọ rẹ wá. *Ps.* Emi o fẹ ọ, Oluwa, agbara mi. Oluwa li alatilẹhìn mi, ibi asalà mi, ati Olugbala mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, ti ojurere gbọ

adura awọn enia rẹ, ki awa t'a npọn l'oju lododo nitori ẹṣẹ wa, k'a lè fi ânu rẹ gbà wa silẹ, nitori ogo orukọ rẹ, kuro ninu gbogbo ijiya ; nipasẹ Jesu-Kristi, etc.

Epistoli (Kor. 9-10).

Enyin ará mi, enyin kò ha mọ pe awọn t'o sáre ije, gbogbo wọn sáre, ṣugbọn enikan l'o gbà ère nâ ? E sáre bẹ, ki enyin ki o lè ri i gbà. Gbogbo awọn t'o jijadu, nwọn ṣe iwọntunwọnsi ninu ohun gbogbo, nwọn sì ṣe e lati gbà adé t'o dibajẹ, ṣugbọn awa lati ri eyi ti kò dibajẹ gbà. Bẹni emi sì nsáre, ṣugbọn kì iṣe bi enití kò mọ ibi t'o nlọ ; bẹni emi njà ṣugbọn kì ṣe bi enikan ti o nlù ofurufu ; ṣugbọn emi njẹ ara mi n'iya, mo mu u sabẹ iteriba, ki emi ba dì eni aṣatì lẹhin ìgbati mo ti wâsu fun elomiran tán. Nitori, ará mi, emi kò fẹ ki enyin k'o ṣe alaimọ pe, gbogbo awọn baba wa ti wà labẹ awọ-sanma, ti gbogbo wọn sì là okun já ; t'a sì ti ọwọ Mose batisi gbogbo wọn ninu awọ-sanma, ati ninu okun ; ti gbogbo wọn ti jẹ onjẹ emí kannâ, ti gbogbo wọn sì ti mu ohun mimu emí kannâ (nitori nwọn nmu omi ninu apata emí ti o ntọ wọn lẹhin, Kristi sì li Apata nâ :) ṣugbọn ọpọlọpọ ninu wọn ni inu Olọrun kò dùn si.

Graduali. Oluwa, Iwọ li oluranlọwọ mi ni ìgba aini ati iponju. Ki awọn ti o mọ orukọ rẹ ki nwọn gbẹkẹle Ọ, nitori Iwọ kò fi awọn ti nṣe afẹri rẹ silẹ. A kì yio gbagbé talaka lailai ; sûru awọn talaka kì yio dasan lailai. Oluwa, dide, máṣe jẹ ki enia buburu ki o bori.

Traktu. Lati inu ibu wá li emi kigbe pè Ọ, Oluwa, Oluwa, gbohùn mi, ję ki etí rę tę̀ silę si ohùn èbę ọmọ-ọdọ rę. Oluwa, bi Iwọ ba fiyesi ę̀ṣę mi, tani yio duro niwaju rę, Oluwa? Ṣugbọn Iwọ kún fun ânu, nitori ofin rę li emi sì gbękęle Ọ, Oluwa

Ihin rere (Mat. 20).

Nigbanâ ni Jesu pa owe yi fun ijọ enia pe : Ijọba ọrun dabi bâle ile ti o jade ni kutukutu owurọ̀ lati gbà awọn alagbaṣe lọ̀ya sinu ọgba ajara rę̀. Nigbati o sì bá awọn alagbaṣe pinnu rę̀ si kọpọ kọkan li ọ́jo, o rán wọn lọ sinu ọgba ajara rę̀. Lakokò wakati ękęta ọjọ́, o sì túnjade, o sì ri awọn alairiṣe miran nduro ni ita, o sì wi fun wọn pe : Ẹ lọ sinu ọgba ajara mi pęlu, eyi ti o ba tọ́ l'emi o fifun nyin, nwọn sì lọ sibę̀. O tún jade lọ lakokò wakati ękęfa ati ękęsan ọjọ́ ; o sì ṣe bę̂. Nigbati o sì jade lọ lakokò wakati ękọkanla ọjọ́, o ri awọn ęlomiran nduro, o sì wi fun wọn pe : Êṣe ti ęnyin fi duro nibi lati onimoni laiṣiṣę? Nwọn wi fun u pe : nitoriti kòsi ęniti o gbà wa lọ̀ya ; o sì wi fun wọn pe : Ẹ lọ sinu ọgba ajara mi pęlu. Nigbati o sì di oju alę, Oluwa ọgba ajara wi fun olutọju ohun rę̀ pe : pè awọn alagbaṣe yi, ki o sì san owo fun wọn, bę̀rę lati ęni ikęhin lọ si ti iṣaju. Nigbati awọn ti a pè lakokò wakati ękọkanla ọjọ́ de, olukuluku wọn gbà kọpọ kọkan. Ṣugbọn nigbati awọn ti o ti ṣaju de, nwọn ṣebi nwọn o gbà jù bę̂ lọ : ṣugbọn olukuluku wọn gbà kọpọ kọkan ; ati ni gbigbà a, nwọn kùn si bâle ile nâ, wípe : Awọn ęni ikę-

hin wọnyi ṣiṣẹ kiki wakati kan li ojọ, iwọ sì mu wọn bá wa ṣe ọgbọgba, awa ti o ti nrù ẹrù, ti a sì gbà oru ojọ. Ṣugbọn o dà ọkan ninu wọn lohùn pe : Ọrẹ, emi kò ṣiṣe si ọ, Iwọ kò ha bá mi pinnu rẹ̀ si kọpọ kan li ojọ bi ? Gbà eyi ti iṣe tirẹ̀, ki o sì mà bá tirẹ lọ. Ṣugbọn emi o fifun ikẹhin yi, gẹgẹ bi mo ti fifun ọ. Tabi kò tọ́ ki emi fi nkan ti iṣe ti emi ṣe bi o ti wù mi ? Oju rẹ korò nitoriti emi ṣe ẹni rere? Bẹ̀ni awọn ẹni ikẹhin yio di ti iwaju. awọn ẹni ikẹhin. Nitoriti ọpọ̀lọpọ̀ li a pè, ṣugbọn diẹ li aọ ri yàn.

Ifitọrẹ. Oluwa, ohun rere ni lati mâ fi iyìn fun Ọ, ati lati mâ kọrin ogo si orukọ rẹ,. Iwọ Ọga-ogo.

Adura ti a kà jẹ̀ẹ́.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, gbà ẹbọ ati adura wa ; wẹ̀ wa nù nipa sakramenti rẹ mimọ́, ki o sì gbọ́ ti wa nitori inurere rẹ, nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Fi ojurere wò ọmọ-ọdọ rẹ, ki o sì gbà mi là nipa ânu rẹ. Oluwa, máṣe jẹ ki oju k'o tì mi, nitori emi kigbe pè Ọ.

Adura lẹhin komunioni.

Olọrun, jẹ ki awọn ẹ̀bun rẹ fun awọn onigbagbọ́ rẹ li agbara, ni gbigbà wọn ki nwọn lè tún ṣe aféri wọn, ati nipa ṣiṣe aféri wọn ki nwọn lè ri wọn gbà titi aiye ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi, etc.

IJỌ ỌSẸ NI SEKSAGESIMA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ji! Oluwa, èṣe ti Iwọ nsùn? Dide, má ṣe ṣa wa tì lai ati lailai! Èṣe ti Iwọ fi yi oju rẹ pada kuro lọdọ wa, ti Iwọ sì ti gbagbé ipọnju wa; inu wa lẹmọ erupẹ ilẹ: Dide, Oluwa, ran wa l'ọwọ, k'o sì gbà wa là. *Ps.* Ọlọrun, awa ti fi etí wa gbọ, awọn baba wa sì rohin fun wa niti iṣẹ nla ti Iwọ ṣe l'ọjọ wọn. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ t'o ri pe, awa kò gbẹkẹle ohunkohun kan ti awa nṣe; nipa ânu rẹ fifun ni, ki a lè tipa èbe Olukọ awọn keferi, dâbobo wa ninu gbogbo ipọnju; nipasẹ Jesu-Kristi, etc.

Epistoli (2 Kor, 11).

Ará mi, ẹnyin t'o jẹ ọlọgbọn fi inudidùn gbà awọn aṣiwère; ani ẹnyin gbà ki a so nyin dẹrú, ki a pa nyin jẹ, ki a jì nyin ni nkan, ki a ṣe igberaga si nyin, ki a gbá nyin loju. Mo nfi itiju wí, bi ẹnipe awa ti jẹ alailera ninu nkan wọnyi. Ṣugbọn ninu ohunkohun ti ẹnikan jẹ ṣefârì (mo nsọ bi aṣiwère), mo lè ṣe bẹ pẹlu. Iṣe Heberu ni nwọn bi? Bẹli emi. Iṣe ara Israeli ni nwọn bi? Bẹli emi. Iṣe irú ọmọ Abrahamu ni nwọn bi? Bẹli emi. Iṣe iranṣẹ Kristi ni nwọn bi? (Emi nsọ bi aṣiwère) mo ta wọn yọ. Niti iṣẹ, pasan, tubu ati ewu ikú mo rekọja wọn. Nigba marun tòto ni mo gbà ilagbà mọkandilogoji lọwọ awọn Ju; nigba

mẹta li a nà mi nipaṣan; nigba kan li a ṣọ mi li okuta; nigba mẹta li ọkọ dà mi. Lọsán ati loru kan ni mo ti wà ninu ibù okun. Nigbakugba ni mo ti wà ni ìrin àjo, ninu ewu loju odò nla, ninu ewu awọn ọlọṣà, ninu ewu awọn ará ilú mi, ninu ewu awọn keferi, ninu ewu làrin ilú, ninu ewu li aginjù, ninu ewu loju okun, ninu ewu làrin awọn eké arakonri, ninu ârẹ ati irora, ninu òpọlọpọ aisùn, ninu ebi ati orùngbẹ, ninu ọpọlọpọ àwẹ, ninu otutù ati ìhoho. Lẹhin nkan wọnyi ti o wà lode, aniyàn ti mo ni fun gbogbo awọn ijọ enia Ọlọrun nwọjọ ti mi lojojumọ. Tani ṣe alailera, ti emi kò ṣe alailera? Tani ẹniti o ri òna atidẹṣẹ, ti ara mi kò gbina? Bi o ba tọ ki emi ṣogo, emi o ṣogo ti kiki irora ati ijiyà mi nikan. Ọlọrun, ti iṣe Baba Oluwa wa Jesu-Kristi, ti a sì fi ibukún fun lailai, mọ pe emi kò ṣeke. Ni Damasku, ẹniti iṣe bãlẹ ilẹ nà t'o wà labẹ Arẹta li o nṣọ ilú awọn ará Damasku lati mu mi, ati l'oju ferese ninu agbọn li a sì ti sọ mi kalẹ lẹhin odi. Bi o ba tọ ki a ṣogo (ani bi kò tilẹ ṣe anfani fun mi lati ma ṣe bẹ), sibẹsibẹ emi o wá si iran ati iṣipaiya ti Oluwa. Mo mọ ọkọnri kan ninu Kristi, o dì iwọn ọdún mẹrinla ti a gbé irú eni bẹ lọ si ọrun kẹta (iṣe ninu ara rẹ tabi l'aisi ara rẹ ni, emi kò mọ, Ọlọrun l'o mọ), mo sì mọ pe a ti gbé irú enia bẹ lọ (iṣe ninu ara rẹ, tabi l'aisi ara rẹ ni emi kò mọ, Ọlọrun l'o mọ) si paridisi, t'o sì ti gbọ ọrọ t'a kò lè sọ, eyiti kò tọ fun enia lati ma sọ jade. Ti irú enia bẹ li emi o ma ṣogo, ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, emi o ma ṣogo ti kiki ailera mi nikan. Ibaṣepe emi fẹ ṣogo, emi kì iba jẹ

aṣiwère, nitoripe emi o sọ otitọ; ṣugbọn mo panumọ́, ki ẹnikan ma ba kà mi si jù bi eyiti o ri ti emi iṣe lọ, tabi jù eyiti o gburó mi si. Ki emi má sì ba ṣe igberaga nitori iṣipaiya nla wọnyi, a ti fi ẹgún gún mi l'ara, ti iṣe iranṣẹ satani (èṣu) lati gbá mi loju. Nitorinâ ni mo ṣe mbẹ Oluwa, ki iranṣẹ èṣu nâ lè kuro l'ara mi. On sì wí fun mi pe: ôre-ọfẹ mi to fun ọ, nitori pe a ṣọ agbara mi di hihàn jù ninu ailera rẹ. Nitorinâ ni emi ma fi inudidùn ṣogo ninu ailera mi, ki agbara Kristi ki o lè ma ba mi gbé.

Graduali. Ki awọn keferi ki o mọ pe oruko rẹ ni Ọlọrun, Iwọ nikanṣoṣo sì ni Ọga-ogo lori aiye gbogbo. Ọlọrun mi, mu awọn ọtá rẹ yika bi kẹkẹ́ ti nyí, ki o sì tú wọn ka bi akeku koriko ti afẹfẹ ngbé kiri.

Traktu. Oluwa, Iwọ ti mu aiye mì, Iwọ sì ti fọ́ ọ; mu fifọ́ rẹ̀ bọ̀ sipò, nitoriti o nmì. Ki awọn ayanfẹ rẹ ki o sá fun ọrún ibinu rẹ, ki a lè gbà wọn là.

Ihin rere (Luk. 8).

Nigbati opọ̀ enia pejọpọ̀, ti nwọn sì ti ilú gbogbo tọ́ Jesu wá, o fi owe sọ̀rọ̀ fun wọn pe: Afọnrugbin kan jade lọ lati fọn irugbin rẹ̀; bi o sì ti nfọnrugbin, diẹ bọ si ẹba ọna, a sì tẹ̀ ẹ mọlẹ, awọn ẹiyẹ oju ọrun sì ṣà a jẹ. Omiran sì bọ sori awọn okuta; bi o sì ti hù jade, o gbẹ nitoriti kò ni irinlẹ-omi. Omiran bọ sinu ẹgún; ẹgún ti o ba a rú soke sì fun u pa. Omi-

ran bọ si ilẹ rere, o sì rú soke, o sì seso ọrọ-run. Nigbati o wí nkan wọnyi tan, o nahùn wí pe : Ẹniti o ba li etí lati gbọ́, ki o gbọ́. Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ si bi i lère kili a mọ̀ owe yi si. O sì wi fun wọn pe : ẹnyin li a fifun lati mọ̀ òrọ-ijinlẹ ijọba Ọlọrun, ṣugbọn ẹlomiran li a powe fun, ti nwọn nri ki nwọn ki o má lè ri, ti nwọn sì ngbọ́ ki o má lè yé wọn. Njẹ owe nâ li eyi : Irugbin li ọ̀rọ Ọlọrun. Awọn ti o bọ si ẹba ọ̀na li awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ nâ, nigbanà ni èṣu wá, o sì mu ọ̀rọ nà kuro li ọkàn wọn, ki nwọn ki o má ba gbagbọ́, ki a má sì ba gbà wọn là. Awọn ti o bọ si okuta li awọn ti o fi ayọ̀ gbà ọ̀rọ nà, nigbati nwọn gbọ́ ọ ; ṣugbọn nwọn kò ni gbòngbo ; nwọn gbagbọ́ nigba diẹ, l'akokò idanwò nwọn sì pada s'ẹhin. Awọn t'o bọ sinu ẹgún li awọn t'o ti gbọ́ ọ̀rọ nâ, ṣugbọn nigbati nwọn ti ba ti wọn lọ, nwọn fi aniyan, ọ̀rọ ati afẹ aiye fun u pa ; tobẹ̀ ti nwọn kò lè seso asogbó ; ṣugbọn awọn t'o bọ si ilẹ rere li awọn t'o gbọ́ ọ̀rọ nà, t'o sì pa a mọ́ ninu ọkàn otitọ ati rere, nwọn sì fi sùru seso.

Ifitọ́ẹ. Fi irìn mi lelẹ ni ipa-ọ̀na rẹ, ki atẹlẹ ẹsẹ̀ mi ki o máṣe yẹ : dẹ etí rẹ si mi, ki o sì gbọ́ ọ̀rọ mi. Fi iṣẹ iyanu ânu rẹ hàn, Oluwa, Iwọ ti o gbà gbogbo awọn t'o gbẹkẹle Ọ là.

Adura t'a kà jẹjẹ.

Oluwa, fifun ni, ki ẹbọ ti a rù si Ọ, ki o lè so wa di alâye, ki o sì lè fun wa l'agbara nigbagbogbo ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Emi o lọ sibi altari Ọlọrun, sọdọ Ọlọrun, ẹniti o kún igbà ewe mi fun ayọ.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ, fifun ni, ki awọn ti Iwọ fi sakramenti rẹ mimọ bọ, ki nwọn lè fi ihùwa ti o wù Ọ sin Ọ bi o ti yẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ NI QUINQUAGESIMA

(*Ọjọ ẹkadọta ṣaju Ajinde Jesu-Kristi*) *tabi Ijọ ọsẹ ti o ṣaju Igba-Awẹ.*

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ki Iwọ ki o je Ọlọrun Alâbo fun mi ati ibi asádi lati gbà mi là; nitori Iwọ ni agbara ati àbo mi; nitori ogo orukọ rẹ li Iwọ o mâ ṣe amọna mi, Iwọ yio si mâ bọ mi. *Ps.* Oluwa, Iwọ ni mo gbẹkẹle: máṣe je ki oju ki o tì mi; gẹgẹbi ododo rẹ gbà mi là, ki o si yọ mi kuro lọwọ awọn ọtá mi. Ogo ni fun Ọlọrun, etc.

Adura.

Oluwa, fi ojurere gbọ adura wa, nigbati Iwọ si ti da wa nide kuro ninu ẹwọn ẹṣẹ, ki Iwọ ki o pa wa mọ kuro ninu gbogbo ipọnju; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Kor. 13).

Ẹnyin ará mi, bi emi tilẹ nfi ède awọn enia ati ti awọn Angẹli sọrọ, ti emi kò ba sì ni ifẹ́ni, emi dabi idẹ ti ndún, tabi bi agogo kekere ti nró gôro. Bi mo tilẹ ni èbun isọtẹlẹ, ti mo sì moyé gbogbo ọ̀rọ ijinlẹ, ti mo sì ni gbogbo imọ̀, ati bi mo tilẹ ni gbogbo igbagbọ́, tobẹ ti mo lè ṣí awọn òke nla nipò, ti emi kò ba sì ni ifẹ́ni, asan ni mi. Ani bi mo tilẹ fi gbogbo ohun ini mi jìn lati fi bọ́ awọn talaka, ti mo sì fi ara mi funni ni sisun ninu iná, ti emi kò ba sì ni ifẹ́ni, kò ṣe ère kan fun mi. Ifẹ́ni amà mu sùru, o sì ṣeun. Ifẹ́ni kì işe ilara; kì işe nkan pẹlu iyajù; kì ifẹ́ soke; kì işe igberaga; kì iwá eyi ti ṣe ti ara rẹ̀; a kì inu binu kankan; kì ighèro ohun buburu; kì iyọ̀ nitori aiṣododo, ṣugbọn a mà yọ̀ nitori otitọ; on ama fi sùru gbà ohun gbogbo; ama gbà ohun gbogbo gbọ́; ama reti ohun gbogbo, ama fi ara da ohun gbogbo. Ifẹ́ni kì o yẹ titi lai. Isọtẹlẹ yio dopin, awọn ède yio n'ipẹkun, ao sì pa imọ̀ rún. Nitoripe a ni imọ̀ aimọ̀tan, awa kò sì nsọ tẹlẹ l'asọtan; ṣugbọn nigbati eyi t'o jẹ pipé bà de, ohunkohun ti kì işe pipé, yio d'opin. Nigbati mo wà l'ewe, emi ama sọ̀rọ bi ewe, emi ama moyé bi ewe, emi a sì ma rò bi ewe; ṣugbọn nigbati mo di ọkọnri tan, mo fi eyiti işe ti ewe silẹ. Nisisiyi awa nri Ọlọrun baibai, bi ẹnipe ninu awojiji; ṣugbọn nigbanâ ni ifojukoju. Nisisiyi mo mọ̀ Ọ li aimọ̀tan, ṣugbọn nigbanâ ni emi o mọ̀ Ọ gẹgẹbi mo ti dì mimọ̀ fun U ati nisisiyi awọn mẹta yi mbẹ, igbagbọ́, ireti ati ifẹ́ni; ṣugbọn eyi t'o tobi julọ ninu wọn ni ifẹ́ni.

Graduali. Ọlọrun, Iwọ nikan l'o nṣe iṣẹ iyanu, Iwọ l'o ti fi agbara rẹ hàn ninu awọn keferi. Iwọ l'o ti fi agbara apa rẹ gbà awọn enia rẹ là, awọn ọmọ Jakọbu ati ti Josefu.

Traktu. Ẹ hó ihó ayọ̀ si Oluwa, ẹnyin aiye gbogbo. Ẹ fi ayọ̀ sin Oluwa. Ẹ ti orin ayọ̀ wá s'iwaju rẹ̀; ki ẹnyin ki o mọ̀ pe Oluwa ni Ọlọrun; on l'o dá wa, kì iṣe awatikalawa; awa l'enia rẹ̀ ati agutan pápa rẹ̀.

Ihin rere (Luk. 18\.

Nigbanâ ni Jesu pè awọn apostoli mejila s'ọdọ rẹ̀, O sì wi fun wọn pe: sawò o, awa ngòke lọ si Jerusalemu, a o sì mu ohun gbogbo ṣẹ, t'a ti kọwe rẹ̀ lat'ọwọ́ awọn woli wá niti Ọmọ enia. Nitori ao fi I le awọn keferi lọwọ́; ao fi I ṣe ẹlẹvà, ao nà A ni paṣan, ao sì tutọ́ si I l'ara. Nigbati nwọn ti nà A ni paṣan tán, nwọn a sì pa A, l'ijọ́ kẹta yio sì tún jinde. Ṣugbọn ọkan ninu nkan wọnyi kò yé wọn; ọ̀rọ̀ yi pamọ́ fun wọn, bẹ̀ni nwọn kò sì mọ ohun t'a wi. O sì ṣe, bi on ti sunmọ́ Jeriko, afọju kan joko lẹba ọ̀na, o nṣagbe. Nigbat'o gbọ́ ariwo awọn enia ti nkoja lọ, O bère kini ṣe? Nwọn sì wi fun u pe Jesu ti Nasareti l'o nkoja lọ. Nigbanâ ni o nkigbe wipe: Jesu, Iwọ Ọmọ Dafidi ṣãnu fun mi. Awọn ti nlọ niwaju ba a wi pe, ki o pa ẹnu rẹ̀ mọ́. Ṣugbọn on kigbe si i kikún wipe, Iwọ Ọmọ Dafidi, ṣãnu fun mi. Jesu sì d'ẹṣẹ̀ duro, o paṣẹ k'a mu u tọ̀ On wá; nigbat'o sì sunmọ́ Ọ, O bi i lère wipe: kini iwọ nfẹ́ ki emi ki o ṣe fun ọ? O sì

wipe : Oluwa, jẹ ki emi lè riran. Jesu sì wi fun u pe : Riran ; igbagbọ́ rẹ li o gbà ọ là. Lojukannâ l'o sì riran, o ntọ lẹhin lọ, o sì nyìn Ọlọrun. Gbogbo awọn enia t'o ri i, ti iyìn fun Ọlọrun.

Ifitọrẹ. Olubukún li Iwọ, Oluwa; kọ́ mi li ilana rẹ. Ẹnu mi li emi ti usọ gbogbo idajọ ẹnu rẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ l'ọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ-ètutu yi ki o pa gbogbo ẹ̀ṣẹ wa rẹ́, ki o sì sọ ara ati ọkàn awọn ọmọ ọdọ rẹ di mimọ́, ki nwọn ki o lè yẹ lati rù ẹbọ mimọ́ yi si Ọ bi o ti yẹ. nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Nwọn jẹ, nwọn sì yó jọjọ : Ọlọrun li o tẹ̀ ifẹ́ inu wọn lọrùn ; olúun gbogbo ti nwọn fẹ́ li O sì fifun wọn.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, jẹ ki onjẹ ọrun yi ti Iwọ fi bọ́ wa ki o lè dàbobo wa ninu gbogbo ipọnju ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ EKINI ÌGBA-ÀWẸ (Lenti

Ti a npè ni Ọjọ́ Wednesday êru.

Ibukún êru.

Orin ti o ṣaju. Oluwa, da wa lohùn, nitoriti ânu rẹ dara; fi ojurere wò wa gẹgẹbi ọpọ ânu rẹ, Oluwa. *Ps.* Ọlọrun, gbà mi là, nitoriti omi ibanujẹ ati ipọnju ṣànbò ọkàn mi mọlẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, dá awọn ti o rònupìwada si, ṣe ojurere si adura wọn, ki o sì fiyesi i lati rán Angẹli rẹ lati ọrun wá, ki o bukún fun êru wọnyi, ki o sì sọ wọn di mimọ́, ki nwọn lè je ohun imularada fun gbogbo awọn ti nfi irẹlẹ ọkàn kigbe pè orukọ rẹ, ti o sì jẹwọ ẹṣẹ ti nwọn jẹbi, ti o sì nsokun fun ẹṣẹ wọn niwaju ânu rẹ, tabi ti nfi irẹlẹ ohùn ati ifọkànsìn bẹ inu rere rẹ; nipa agbara orukọ rẹ mimọ́ julọ fi funi, ki gbogbo awọn eniti a o fi êru yi sí niwaju orí nitori imukuro ẹṣẹ wọn, lè ri gbogbo ôre-ọfẹ ti nwọn nṣe alaini fun ara ati ọkàn wọn gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Adura ikẹhin.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o dari ẹṣẹ jì awọn ará Ninifiti ti o rònupìwada nitôtọ ninu aṣọ ọfọ ati ninu êru, nipa ânu rẹ fi funi, pe ni titọpasẹ wọn ninu irònupìwada wọn ki a lè ri idariji ẹṣẹ wa gbà gẹgẹbi wọn. nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Nigbati saserdoti ṣe ipinfuni êru, a kọ orin tio tẹle eyi.

1. Ẹ fi aṣọ ọfọ paro aṣọ nyin, ki ẹ si fi ara nyin yilẹ êru ; ẹ jẹ ki a gbàwẹ, ki a si damije niwaju Olọrun, nitoripe Olọrun wa kún fun ânu, yio si dari èṣẹ wa ji wa.

2. Jẹ ki awọn saserdoti, iranṣẹ Oluwa, sọkun lârin iloro ati altari, ki nwọn si wipe : Oluwa, dá awọn enia rẹ si, dá wọn si ; máṣe dí awọn ti nkọrin iyìn rẹ lẹnu.

3. Ẹ jẹ k'a ṣe atunṣe èṣẹ ti a da nipa aimọ̀, boya a ki yio ri àye lati rònupiwada, bi ikú ba bá wa lojiji.

4. Fetisi wa, Oluwa, ki o si ṣânu fun wa, nitoriti a dẹṣẹ si O. Olọrun Olugbala wa, ran wa lọwọ, ki o si gbà wa là nitori ogo orukọ rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Nigbati saserdoti fi êru si awọn onigbagbọ niwaju ori, o wi pe : Iwọ enia, ranti pe erupẹ ni iwọ, iwọ o si pada di erupẹ.

Adura.

Oluwa, fun wa li òre-ọfẹ lati bẹrẹsi ogun Kristiani jà nipa àwẹ mimọ́, pe bi a ba ni lati ṣigun si ẹmi arekereke ati òkunkun, ki awa lè ri iranlọwọ ti a nṣe alaini gbà ninu àwẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA NI WEDNESDAY ÈRU

Ipilęsę ti Misa. Ọlọrun, Iwọ ṣânu fun gbogbo awọn ẹdá rẹ, Iwọ kò si korira ọkan ninu wọn ; Iwọ mu oju rẹ kuro ninu ẹṣẹ awọn enia nitori irònupiwada, Iwọ sì da wọn si, nitoriti Iwọ jẹ Oluwa Ọlọrun wa. *Ps.* Ṣânu fun mi, Ọlọrun, ṣânu fun mi, nitoriti ọkàn mi gbẹkẹle Ọ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, fi òre-ọfẹ fun awọn onigbagbọ rẹ lati fi ifọkansìn tôtọ bẹ̀rẹ igba àwẹ mimọ́ yi, ati lati fi ọkàn mimọ́ ati idakẹjẹ de opin rẹ̀ fun igbalà wọn ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Adura fun âye on okú.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o jọba lori âye on okú, Iwọ ti o sì ṣânu fun gbogbo awọn ẹniti Iwọ ti mọ̀ tẹlẹ pe yio gbiyanju: nipa igbagbọ́ ati iṣẹ-rere lati jẹ tirẹ, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹ̀bẹ lọdọ rẹ, nipa èbẹ gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ, jẹ ki awọn ẹniti awa gbiro lati gbadua fun, yala nwọn wà l'aiye yi nisisiyi, tabi nwọn ti pada lọ si aiye ti kò nipẹkun, lè ri idariji gbogbo ẹṣẹ wọn gbà lọdọ ânu rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Joeli 2).

Oluwa wí nkan wọnyi pe : Ẹ fi gbogbo ọkàn

nyin yí pada si mi, pẹlu àwẹ, pẹlu ẹkún ati pẹlu ọ̀fọ. Ẹ fà aiya nyin ya, kì iṣe aṣọ nyin, ki ẹnyin sì yí pada si Oluwa, Ọlọrun nyin ; nitoriti O ṣeun, O sì kún fun iyọnu, kì ibinu kankan, O sì pọ̀ li ânu, inu rẹ̀ sì bajẹ nitori ohun buburu ti o ti ṣe ileri lati rán si wa. Tali o mọ̀ bi on ò yí pada si wa, ti on ò darijì wa, ti on ò sì fi ibukún silẹ lehin rẹ̀, ki ẹnyin lè rù ẹbọ ohun jijẹ ati ẹbọ ohun mimu si Oluwa Ọlọrun nyin. Ẹ fun ipè ni Sioni : ẹ ya àwẹ kan si mimọ́, ẹ pe apejọ. Ẹ kó awọn enia jọ, ẹ wẹ ijọ enia mọ́, ẹ pè awọn àgba jọ, ẹ kó awọn ọmọde jọ, ati awọn ti nmu ọmu ; jẹ ki oko iyawo jade kuro ninu akete rẹ̀, ati iyawo kuro ninu iyẹ̀wu rẹ̀. Jẹ ki awọn saserdoti, iranṣẹ Oluwa, sọkun lârin iloro ati altari, ki nwọn si wipe : da awọn enia rẹ si, Oluwa, da wọn si, má ṣe jẹ k'a k'ẹgan ijọgún rẹ, ki awọn keferi má ṣe jọba l'ori wọn. Eṣe ti nwọn o fi wi ninu awọn enia pe : Ọlọrun wọn ha da? Ọlọrun ṣ'ájo ilẹ rẹ̀ ; O darijì awọn enia rẹ̀. Oluwa dahùn, O sì wí fun awọn enia rẹ̀. pe : Wò o, emi o ran ọkà, oti vini ati ororo si nyin, ao sì fi wọn tẹ́ nyin l'ọrun ; lai emi kì yío fi nyin silẹ fun ẹgan awọn keferi mọ́, ni Oluwa Ọlodumare wí..

Graduali. Ṣânu fun mi, Oluwa ; ṣânu fun mi ; nitori Iwọ ni ọkàn mi gbẹkẹle. Iranlọwọ́ ni o nran lat'ọrun wá, O gbà mi là, O sì jẹ ki oju tì awọn ti ntẹ̀ mi mọ́ ilẹ.

Traktu. Oluwa, máṣe hùwa si wa gẹgẹ bi ẹṣẹ wa, bẹ̀ni má ṣe san a fun wa gẹgẹ bi aiṣe dédé wa. Oluwa má ṣe ranti ẹṣẹ wa t'o ti koja,

ṣugbọn jẹ ki ànu rẹ ṣaju wa, nitori òṣi bò wa mọlẹgidigidi. Ran wa l'ọwọ́, Ọlọrun Olugbala wa, ki o gbà wa là nitori ogo orukọ rẹ, ki o sì dari ẹṣẹ wa jì wa nitori orukọ rẹ.

Ihin rere (Mat. 6).

Nigbanâ ni Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : nigbati enyin ba ngbàwẹ, ẹ má ṣe fajuro bi awọn agabagebe ; nitori nwọn mba oju jẹ, ki awọn enia lè ri pe nwọn ngbàwẹ. Lõtọ ni mo wi fun nyin ; nwọn ti gbà ère wọn nâ. Ṣugbọn iwọ, nigbati iwọ ba ngbàwẹ, fi oróro kùn orí rẹ, ki o sì wẹ oju rẹ, ki awọn enia máṣe mọ pe iwọ ngbàwẹ, bikoṣe Baba rẹ ti mbẹ ni ìkọkọ ; Baba rẹ ti o sì riran ni ikọkọ yio san a fun ọ. E máṣe kó iṣura jọ fun ara nyin li aiye, nibiti ipara ati kòkoro bà a jẹ, ati nibiti awọn olè runlẹ, ti nwọn sì jale. Ṣugbọn ẹ kó iṣura jọ fun ara nyin li ọrun, nibiti ipara ati kòkoro kò lè bà a jẹ, ati nibiti awọn olè kò lè runlẹ ki o jale. Nitori nibiti iṣura nyin gbé wà, nibẹ ni ọkàn nyin yio gbé wà pẹlu.

Ifitọrẹ. Oluwa, emi o gbé Ọ ga, nitoriti Iwọ gbà mi sàbẹ âbo rẹ, ti Iwọ kò sì jẹ ki awọn ọtá mi yọ̀ mi.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodo rẹ, mu wa ye lati rù ẹbọ yi si Ọ bi o ti yẹ, nipa eyiti a ṣe iranti iṣedalẹ sakramenti mimọ́ yi ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun âye on okú.

Olorun, Iwọ nikan ti iyè awọn ayanfẹ ti yio de ibi alafia ainipẹkun dì mimọ́ fun, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fifuni nipa ẹbẹ gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ. ki a lè kọ́ orukọ gbogbo awọn ẹniti awa ngbadua lọdọ rẹ fun sinu iwe iyàntẹlẹ si ìye alafia pẹlu ti gbogbo awọn onigbagbọ́; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹnikẹni ti o ba nṣe aṣaro ofin Oluwa lọsan ati loru, yio seso rẹ̀ pade li akokò rẹ̀.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, nipa agbara sakramenti mimọ́ ti awa gbà, fun wa l'iranlọwọ́ ti a nṣe alaini, ki àwẹ wa lè wù Ọ, ki o si lè ṣe anfani fun igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura fun âye on okú. Olorun Olodumare ati alânu julọ, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fifun ni, ki sakramenti ti awa gbà ki o lè wẹ̀ wa nù, ati nipa ẹbẹ gbogbo awọn enia mimọ́ rẹ má si ṣe je ki sakramenti nâ lè ṣe idalẹbi fun wa, bikoṣe ẹbẹ alagbara lati ri idarijì ẹ̀ṣẹ wa gbà; ki o wẹ̀ ẹ̀ṣẹ wa nù, ki o fun awa alailẹra lagbara, ki o si ṣe âbo wa ninu ewu aiye; nikẹhin ki o si ṣe idarijì ẹ̀ṣẹ fun gbogbo awọn onigbagbọ́ t'âye ati t'okú; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ EKINI NI IGBA-ÀWẸ

(Quadragesima, tabi Lenti).

Ipilẹṣẹ ti Misa. On o kigbe pè mi, emi o sì da a lohùn, emi o gbà kuro ninu ewu, emi o sì yìn i logo; ẹmi gigun l'emi o fifun u. *Ps.* Ẹniti ọ wà labẹ iranlọwọ Ọga-ogo ni yio ma gbé abẹ âbo Ọlọrun Olodumare. Ogo ni fun Baba, ete.

Adura

Ọlọrun, Iwọ ti o ti wẹ ijọ enia rẹ nù lodo-dún nipa àwẹ ogoji ọjọ, fifun awọn ará ile rẹ, nipa iṣẹ rere won ki nwọn lè ri eyiti nwọn gbiyanju ki nwọn lè ye fun nipa gbigbàwẹ gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Epistoli (2 Kor. 6).

Ará mi, awa ngbà nyin niyanju lati máṣe gbà ôre-ọfẹ Ọlọrun lasan, nitori o wipe : Emi ti gbohùn rẹ li akokò itẹwọgbà, emi sì ti ran ọ lọwọ li ọjọ igbalà. Kivesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọghà, kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbalà. Jẹ ki awa máṣe fun ẹnikeji li ọna imunidẹṣẹ, ki a má ba sòro odi si iṣẹ saserdoti wa, ṣugbọn ni ohun gbogbo ki awa farahàn bi iranṣẹ Ọlọrun nipa ọpọlọpọ sùru ninu ipọnju, ninu aini, ninu wahalà, labẹ pasan, ninu tubu, ninu isọtẹ, ninu iṣẹ, ninu aisùn, ninu igbàwẹ ; nipa iwa mimó, nipa ọgbón, nipa ipamọra, nipa iṣeun, nipa Emi-Mimó, nipa ifẹ aisètan, nipa ọrọ otitó, nipa agbara Ọlọrun, nipa ihamọra ododo

li apa ọtún ati li apa òsin ; ninu ọlá ati ẹgan, ninu okiki buburu ati rere ; ibâṣe a kà wa si bi ẹni ẹlẹtan, bi awa tilẹ jẹ olôtọ ; bi ẹniti a kò mọ, bi awa tilẹ dì mimọ dajudaju ; bi ẹniti nkú lọ, sì kiyesi i, awa wà lâye ; bi ẹniti a nnà, ṣugbọn ti a kò pa ; bi ẹniti o kún fun ibanujẹ, ṣugbọn awa wà ninu ayọ nigbaghogbo ; bi talaka, ṣugbọn awa nṣo ọpọlọpọ dì ọlọrọ ; bi ẹniti kò ni nkan, ṣugbọn awa ni iní nkan gbogbo.

Graduali. Ọlọrun fi aṣẹ fun awọn Angẹli rẹ lati mâ ṣe itọju rẹ li ọna rẹ gbogbo. Li ọwọ wọn ni nwọn o gbé ọ soke, ki iwọ ki o má ba fi ẹsẹ rẹ ṣán okuta.

Traktu. Ẹniti o wà labẹ iranlọwọ Ọga-ogo, ni yio mà gbé abẹ âbo Ọlọrun Olodumare. On o wí fun Oluwa pe : Iwọ li odi ati ibi-asalà mi ; Ọlọrun mi. Iwọ li emi gbẹkẹle. Nitoriti o gbà mi kuro ninu ikẹkun awọn ọdẹ, ati ninu ọrọ lile awọn enia buburu. Ejiká rẹ yio ṣi ọji bò ọ mọlẹ, ati labẹ iyẹ apa rẹ ni iwọ yio ri igbẹkẹle. Otitọ rẹ yio yi ọ ká bi asà ; iwọ kì yio bẹru nitoriti ẹru oru, tabi fun ọfà ti nfò lọsán, tabi fun ohun ti nrìn kiri li òkunkun, tabi fun ikọlú èṣu ọsán gangan. Ẹgbẹrun yio ṣubu li ẹgbẹ rẹ, ati ẹgbarun li apa ọtún rẹ, ṣugbọn ọkan ninu wọn kì yio sunmọ ọdọ rẹ. Ani iwọ fi oju rẹ wò, iwọ o sì ri ijiya awọn ẹlẹṣẹ. Nitoriti iwọ wipe : Oluwa, Iwọ ni ireti mi ; ti iwọ sì yàn Ọga-ogo bi ibi âbo rẹ. Ohun buburu kan kì yio wá sọdọ rẹ, bẹni ajakalẹ-arùn kì yio sunmọ ile rẹ. Nitori ti yio fi aṣẹ fun awọn Angẹli rẹ lati ṣe itọju rẹ li ọna rẹ gbogbo ; li

ọwọ́ wọn ni nwọn o gbé ọ soke, ki iwọ má ba ti ẹsẹ rẹ ṣán okuta : Iwọ o kọja lori paramọlẹ ati akerekere, kiniu ati dragoni (ejo buburu abiyẹ) ni iwọ o fi ẹsẹ tẹ mọlẹ. Nitoriti o gbẹkẹle mi, nitorinâ li emi o ṣe gbà a là; emi sì jẹ alâbo rẹ, nitoriti o mọ orukọ mi. On o kigbe pè mi, emi o da a lohùn ; mo wà pẹlu rẹ li akokò ipọnju, emi o gbà a silẹ, emi o sì yìn i logo. Ẹmi gigùn li emi o fifun u, emi o sì fi igbalà mi hàn a,

Ihin rere (Mat. 4).

Nigbanâ ni a darí Jesu si ijù lati ọwọ́ Ẹmi lati dán a wò lọwọ́ èṣu. Nigbati o ti gbâwẹ li ogoji ọsán ati ogoji oru, ebi npa a. Oludanwò sì de ọdọ rẹ, o wipe : bi iwọ ba iṣe Ọmọ Ọlọrun, wi fun awọn okuta wọnyi, ki nwọn di akara. Ṣugbọn O dahùn wipe : A ti kọwe rẹ pe : Enia kò wà nipa akara nikan, bikoṣe nipa gbogbo ọrọ t'o ti ẹnu Ọlọrun jade wá. Nigbanâ ni èṣu gbé e lọ si ilú mimọ́, o sì gbé e le ṣonṣó òke ile Ọlọrun, o si wi fun U pe : bi Iwọ ba iṣe Ọmọ Ọlọrun, bẹ silẹ fun ara rẹ; nitori a ti kọwe rẹ pe : O fi aṣẹ fun awọn Angẹli rẹ lati ṣe itọju rẹ, nwọn yio sì gbé ọ soke li ọwọ́ wọn, ki iwọ ki o má ba ti ẹsẹ rẹ ṣán okuta. Jesu dahùn wi fun u pe : A sì tún kọwe rẹ pe : Iwọ kò gbọdọ dán Ọlọrun, Oluwa rẹ wò. Ẹṣu sì tún gbé e lọ sori òke giga fiofio, o sì fi gbogbo ilẹ ọba aiye ati ogo wọn hàn a, o sì wi fun u pe : Gbogbo nkan wọnyi li emi o fifun ọ, bi iwọ ba wólẹ, ti iwọ sì foribalẹ fun mi. Nigbanâ ni Jesu wi fun u pe :

Kuro lọdọ mi, sa!ani, nitoriti a kọwe rẹ pe : Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o foribalẹ fun, on nikanṣoṣo ni ki iwọ sì mâ sìn. Nigbanâ ni èṣu fi i silẹ lọ, sì kiyesi i, awọn Angẹli tọ ọ wá, nwọn sì nsìn I.

Ifitorẹ. Ejiká Oluwa yio ṣi ojî bò ọ mọlẹ, labẹ iyẹ apa rẹ ni iwọ o ri igbẹkẹle; otitọ rẹ yio yi ọ ká bi asà.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa fi irònu rù ẹbọ yi si Ọ li ipilẹṣẹ àwẹ ogoji ọjọ, awa sì mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifuni nipa ôre-ọfẹ rẹ, pe ni didi onjẹ ara kùn, ki a lè daraduro pẹlu kuro ninu afẹ ara ti o lè ba wa jẹ lọkàn; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Komunioni. (*O ri bakannâ bi ti Ifitorẹ*).

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki sakramenti rẹ mimọ ti a rù si Ọ lè mu agbara wa bọsipo, nigbati o si ti wẹ wa nù kuro ninu idibajẹ atijọ wa tán, ki o lè ṣọ wa di alabapín ninu ọrọ ijinlẹ ti igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ EKEJI NI IGBA-ÀWẸ

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ranti ânu ati iṣeun rẹ ti Iwọ nlihàn nigbagbogbo; máṣe jẹ ki awọn ọtá wa k'o jọba lori wa. Ọlọrun Israeli,

gbà wa kuro ninu gbogbo ipọnju wa. *Ps.* Oluwa, Iwọ ni mo gbé ọkàn mi s'oke si; Ọlọrun mi, Iwọ ni mo gbẹkẹle, má ṣe jẹ ki oju ki o tì mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ t'o ri pe awa kò ni agbara kan fun ara wa, pa wa mọ ninu ati l'ode, ki a lè dâbobo wa ninu gbogbo ipọnju t'o lè de si wa l'ara, ki a sì lè wẹ wa nù kuro ninu gbogbo iromu buburu t'o lè ba wa jẹ l'ọkàn; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Tess. 4).

Ará mi, awa nfi Oluwa Jesu bẹ nyin, awa sì ngbà nyin ni iyanju pe, bi ẹnyin ti kọ lat'ọwọ wa, bi ẹnyin iba ti ma rìn l'ọna Ọlọrun lati wù U, bẹ̀ẹ̀gẹ̀gẹ̀ ni ki ẹnyin ki o ma rìn tobẹ̀, ti ẹnyin lè ma lọ siwaju si i ninu rẹ̀. Nitori ẹnyin ti mọ irú ofin t'a ti fi fun nyin l'at'ọwọ Oluwa Jesu; nitori eyi l'ifẹ Ọlọrun, ìwa mimọ nyin; ki ẹnyin takété si àgbere; ki olukuluku nyin ki o mọ lati lò èlo ara rẹ ni mimọ, ati ni olá; kì iṣe ni ti tele ifẹkufẹ ara gẹgẹ bi awọn keferi ti kò mọ Ọlọrun ti iṣe. Ki ẹnikẹni ki o má ṣe ni ẹnikeji rẹ l'ara, ki o má sì ṣe rẹ ẹ jẹ li ohunkohun, nitoripe Oluwa ni iṣe olugbẹsan irú gbogbo èṣẹ bawọnyi, gẹgẹ bi awa ti so fun nyin ni iṣaju, t'a sì ti mu da nyin l'oju. Nitori Ọlọrun kò pè wa si ìwa èri, bikoṣe si ìwa mimọ ninu Jesu-Kristi Oluwa wa.

Graduali Ipọnju aiya mi di pupọ; Oluwa, gbà mi kuro ninu isẹ mi. Wò iwa irẹlẹ mi ati ikẹdùn mi, ki o sì dari gbogbo ẹṣẹ mi jì mi.

Traktu. Ẹ fi iyìn fun Oluwa, nitoriti o ṣeun, nitoriti ãnu rẹ duro lailai. Tal'o lè sọ isẹ agbara Oluwa jade bi o ti yẹ? Tal'o sì lè fi gbogbo iyìn rẹ hàn? Alabukún fun ni awọn ti npa ofin Ọlọrun mọ, ti o sì nṣe ododo nigbaghogbo. Oluwa, ranti wa gẹgẹbi ifẹ ti iwọ ni si awọn enia rẹ; fi igbalà rẹ bẹ wa wò.

Ihin-rere (Mat. 17).

Nigbanâ ni Jesu mu Peteru, Jakọbu, ati ati Johanu arakọnri rẹ, o sì mu wọn wá sori òke giga, li apakan. Ara rẹ sì yipada niwaju wọn, oju rẹ sì ndán bi ôrùn, aṣọ rẹ sì fún bi imọlẹ. Sì kiyesi i, Mose ati Eliasi yọ si wọn: nwọn mbá A sọrọ. Nigbanâ ni Peteru wi fun Jesu pe: Oluwa, o dara fun wa ki awa mâ gbé bi; bi Iwọ ba fẹ, jẹ ki a pa agọ mẹta nibi: ọkan fun Iwọ, okan fun Mose, ati ọkan fun Eliasi. Bi o ti nwí lọwọ, kiyesi i, ikuku ti o mọlẹ ṣijibò wọn, ohùn kan sì ti inu ikuku jade wá, ti o wi pe: Eyiyi ni ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi; ẹ mà gbọ tirẹ. Nigbati awọn ọmọ-ẹhin rẹ gbọ, nwọn dojubọlẹ, ẹru sì bà wọn gidigidi. Jesu sì sunmọ wọn, o fi ọwọ bà wọn, o sì wí fun wọn pe: Dide, ẹ máṣe bẹru. Nigbati nwọn gbé oju soke, nwọn kò ri enikan, bikoṣe Jesu nikan. Bi nwọn sì ti nti ori òke sọkalẹ, O kilọ fun wọn pe: Ẹ máṣe sọrọ iran nà fun enikan tibi Ọmọ-Enia yio fi tún jinde kuro ninu okú.

Ifitọrẹ. Nigbagbogbo li emi o mâ ṣe aṣaro ofin rẹ, Ọlọrun, nitori mo fẹ́ Ẹ gidigidi ; emi o sì gbé ọwọ́ mi s'oke lati mu aṣẹ rẹ ṣẹ. eyiti inu mi dùn si gidigidi.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi oju rere gbà ẹbọ yi, ki o lè ran wa lọwọ́ lati lọ siwaju ninu ifọkansìn, ati lati ri igbalà ainipẹkun gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Gbọ́ igbe mi, ọba ati Ọlọrun mi, fiyesi ohùn adura mi ; nitoripe ọdọ rẹ nikan l'emi o mâ gb'adura si, Oluwa.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹ̀bẹ l'ọdọ rẹ, fifun ni, ki awọn ẹniti Iwọ fi sakramenti rẹ mimọ́ bọ́, lè fi ihùwa ati iṣe t'o wù Ọ, sìn Ọ b'o ti yẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸTA NIGBA ÀWẸ

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oju mi gbe soke si Oluwa lai, nitoriti yio fà ẹsẹ̀ mi yọ kuro ninu awọn ti a dẹ fun mi. Yipada si mi, k'o sì ṣânu fun mi, Ọlọrun mi, nitoriti a kọ̀ mi silẹ, mo sì di olupọnju. *Ps.* Oluwa, Iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si ; Iwọ ni mo gbẹkẹle, Ọlọrun mi ; má ṣe jẹ ki oju k'o tì mi. Ogo ni fun Baba, etc.

. *Adura.*

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fiyesi ẹbọ awọn onirẹlẹ ọkàn, k'o sì nà ọwọ́ ọtún ti Ọlá-nla rẹ jade lati dàbobo wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ef. 5).

Arà mi, ẹ mâ ṣe afarawe Ọlọrun bi awọn ọmọ ọwọ́n ; ki ẹ sì mâ rìn ninu ifẹ, gẹgẹbi Kristi pẹlu ti fẹ wa, ti o sì fi ara rẹ fun wa bi ọrẹ fun Ọlọrun, ati bi ẹbọ òrun didùn. Ṣugbọn àgbere ati gbogbo ìwa èri, tabi ojukòkoro, ki a máṣe darukọ rẹ lârin nyin mọ́, gẹgẹbi o ti yẹ fun awọn enia mimọ́. Ki a máṣe gbọ́ ọ̀rọ̀ aimọ́, tabi ọ̀rọ̀ iwère. tabi iṣẹfẹ mọ́, awọn ti kò yẹ fun ipè nyin, ṣugbọn ẹ kuku mâ sọ ọ̀rọ̀ idupẹ. Nitori ẹ mọ̀ pe kò si panṣaga, tabi alaimọ́ enia, tabi olojukòkoro, ti iṣe ibọrisa, ti yio ni ijogún kan ni ijọba Kristi ati ti Ọlọrun. Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni fi ọ̀rọ̀ asan tàn nyin jẹ ; nitori nkan wọnyi l'o mu ibinu Ọlọrun wá sori awọn ọmọ alaigbagbọ́. Nitorinà ẹ máṣe jẹ alajọpin wọn ; nitori ẹnyin ti jẹ òkunkun nigbakanri, ṣugbọn nisisiyi ẹnyin dì imọlẹ nipa ôre-ọfẹ Oluwa. Ẹ mâ rìn bi ọmọ imọlẹ, nitoripe eso imọlẹ ni gbogbo iṣeun, ododo ati otitọ.

Graduali. Oluwa, dide, máṣe jẹ ki enia buburu ki o bori ; jẹ ki a ṣe idajọ awọn keferi niwaju rẹ gẹgẹbi ọ̀pọ̀ èṣẹ wọn. Nigbati ọ̀tá mi ba pẹhinda, awọn enia buburu ṣubu, nwọn o sì ṣegbé niwaju rẹ.

Traktu. Ọlọrun, Iwọ ti ugbé inu ọrun li emi o gbé oju mi soke si. Bi awọn iranṣẹ kọnri ti mâ tẹjumọ ọwọ awọn olori wọn, ati bi iranṣẹ birin ti mâ tẹjumọ ọwọ iyálode rẹ, bẹni awa ntẹjumọ Oluwa, Ọlọrun wa titi yio fi ṣânu fun wa.

Ihin rere (Luk. 11).

Nigbanâ ni Jesu nlé èṣu kan ti o yadi jade. Nigbati èṣu nâ sì jade, odi nfọhùn, ẹnu sì ya awọn enia, ṣugbọn awọn ẹnikan ninu wọn wi pe : Ọlá Belsebu, olori awọn èṣu, li o fi nlé awọn èṣu jade. Awọn ẹlomiran sì ndan a wó nwọn sì mbère àmi kan l'ọwọ rẹ lat'ọrun wá. Ṣugbọn nigbati Jesu ri ìro inu wọn, o wi fun wọn pe : Gbogbo ijọba t'o yà ara rẹ ni ipa'ao sọ di ahoro, ile yio sì wólù ile miran. Nje bi satani ba yàpa si ara rẹ, bawo ni ijọba rẹ yio ṣe duro ? Nitoriti ẹnyin wipe : emi nfi ọlá Belsebu lé awọn èṣu jade. Bi o ba ṣe pe ọlá Belsebu li emi fi nlé awọn èṣu jade, ọ'á tani awọn ọmọ nyin fi nlé wọn jade ? Nitorinâ ni wọn yio ma jẹ onidajọ nyin. Ṣugbọn b'o ba ṣe pe ika Ọlọrun l'emi fi nlé awọn èṣu jade, lôtọ ni ijọba Ọlọrun de ọdọ nyin. Nigbati ọkọnri alagbara t'o hamọra ba nṣọ ile rẹ ; gbogbo nkan t'o ni a wà l'alafia. Ṣugbọn nigbati ọkọnri alagbara jù on lọ ba kọlù u, t'o sì ṣẹgun rẹ, o gbà gbogbo ihamọra rẹ, ti o gbẹkẹle, a sì pin gbogbo ikogun rẹ. Eniti kò wà pẹlu mi. O nṣe òdi si mi, eniti kò ba mi kójọpọ, o nfọn kakiri. Nigbati ẹmi aimọ nâ ba jade kuro lara enia, a ma rìn kiri ni ibi gbigbẹ, a ma wá ibi isimi ;

bi kò sì ti ri i, o wipe : emi o pada lọ s'ile mi, nibiti mo ti jade, nigbat'o sì de, o bá a, a gbà a, a sì ṣe e l'ọṣọ́. Nigbanà ni o lọ, o sì mu ẹmi meje miran t'o buruju on tikalarẹ lọ ; nwọn wọle, nwọn sì joko nibẹ. Asẹhinìwà ọkọnri nâ o buruju ti isaju rẹ lọ. O sì ṣe, bi o ti nso nkan wọnyi, obiri kan nahùm ninu awujọ, o sì wi fun Ù pe : Ibukún ni fun inu t'o bí Ọ, ati ọmú ti Iwọ mu. Ṣugbọn On wi pe : Nitòtọ, ki a kuku wípe : Ibukún ni fun awọn ti ngbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun, ti nwọn sì npa a mọ́.

Ifitọrẹ. Awọn ofin Oluwa ni otito, nwọn sì nkún ọkàn fun ayọ̀ ; ofin rẹ dùn jù oyin ati afara oyin lọ ; nitorinà ni iranṣẹ rẹ ti tifetifẹ pa a mọ́, Ọlọrun.

Adura ti a hà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki hostia yi lè wẹ wa nù kuro ninu ẹṣẹ wa, ki o sì lè sọ awọn ọmọ-ọdọ rẹ di mimọ́ si Ọ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Olokoṣẹ ri ile, òdere kòko sì ri itẹ́ kan lati tì ọmọ rẹ̀ sì. Altari rẹni ibugbemi, Oluwa awọn ọmọ-ogun, ọba mi ati Ọlọrun mi. Alabukúnfun ni awọn ti ngbé inu ile rẹ ; nwọn o mâ yìn Ọ lai ati lailai.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Iwọ ti o sọ wa di alabapin ninu sakramenti rẹ mimọ́, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, nipa ânu rẹ ki o gbà wa pẹlu kuro ninu gbogbo ẹṣẹ ati ewu ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ ẸKẸRIN NI IGBA-ÀWẸ

Ipilẹṣẹ ti Misa. Yọ, Jerusalemu. ẹ kó ara nyin jọ, gbogbo ẹnyin ti o fẹ ẹ. Ẹ bá a yọ ayọ, gbogbo ẹnyin ti nsọkún fun u ; ẹ yọ, ki a sì fi ọmú itunu rẹ tẹ nyin lọrùn. *Ps.* Inu mi dùn, nigbati nwọn wi fun mi pe : Ẹ jẹ ki a lọ si ile Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lodọ rẹ; fifunni, ki awa ti a pọn loju f'ọna ododo nitori ẹṣẹ wa, ki a lè fi itunu ôre-ọfẹ rẹ tù wa f'ara, nipasẹ Jesu-Kristi wa Oluwa. Amin·

Epistoli (Gal. 4).

A ti kọwe rẹ pe : Abrahamu li ọmọkọnri meji, ekini nipa ẹrú-obiri ; ekeji nipa omnira obiri. Ṣugbọn eyiti iṣe nipa ẹrú-obiri li a bí nipa ti ara, ati eyi ti omnira-obiri nipa ileri Olọrun. Nkan wọnyi li a wi nipa ifọranweran, nitoripe obiri meji wọnyi jasi majẹmu meji yi; ekini t'a da lori òke Sinai, t'o sì bí ẹrú ni Hagari. Nitori Sinai ni òke kan ni Arabia, ti iṣe aworan Jerusalemu t'o wà nisisiyi. t'o wà li oko-ẹrú pẹlu awọn ọmọ rẹ. ṣugbọn omnira ni Jerusalemu t'o wà loke ti iṣe iyá gbogbo wa. Nitoriti a ti kọwe ni tirẹ pe : ma yọ, iwọ àgan ti kò bímọ, hó ihó ayọ, iwọ ti kò rọbi ri; nitoripe ẹni-kikọsilẹ ni ọpọlọpọ ọmọ jù ẹniti iṣe abileko lo. Nje nitorinâ, arâ, awa ni iṣe awọn ọmọ ileri, gẹgẹ bi Isaaki. Ṣugbọn bi

igbanà ẹnit'a bí nipa t'ara ti iṣe inunibini si ẹnit'a bí nipa t'ẹmi gẹgẹ bẹ̀ l'o ri nisisiyi. Ṣugbọn kini iwe mimọ́ wí? Lé ẹrú-obiri nà ati ọmọ rẹ̀ jade. nitori pe ọmọ ẹrú-obiri kì yio ba ọmọ omnira obiri ṣe ajumọ́ jogún pọ̀. Bi o ṣe ti wa ni, ará, awa kì iṣe ọmọ ẹrú obiri bikoṣe ti omnira nâ ni Jesu-Kristi ti ṣo wa di omnira.

Graduali. Inu mi dùn nigbati nwọn wi fun mi pe : ẹ jẹ ki a lọ si ile Oluwa. Ki alafia ki o wà ninu odi rẹ, ati ibukún ninu afin rẹ.

Traktu. Awọn ti o gbẹkẹle Oluwa dabi òke Sioni ti a kò lè ṣinidi ; ẹniti o gbé inu Jerusalemu kì yio lè mì lai. Bi òke nla ti yi Jerusalemu ká, bẹ̀ni Oluwa yí awọn enia rẹ̀ ká lati isisiyi lọ ati titilailai,

Ihin rere (Joh. 6).

Nigbanà ni Jesu koja si apakeji okun Galili, ti iṣe adagun Tiberia, ọpọ enia sì ntọ̀ Ọ lẹhin, nitoriti nwọn ri iṣẹ iyanu rẹ̀ ti o ṣe si awọn alarùn. Jesu sì gún òke lọ, nibẹ̀ li o si gbé joko pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀. Ijọ́ ọdún irekoja ti awọn Ju sì sunmọ́ etile. Nigbati Jesu sì gbé oju rẹ̀ soke, ti o sì ri ọpọ enia wá sọdọ rẹ̀, O wi fun Filippi pe : Nibo li ao ti rà akara to, ki awọn wọnyi lè jẹ? Ṣugbọn O sọ eyi lati dan a wò ; nitoriti ontikalarẹ̀ mọ̀ ohun ti on ṣe. Filippi da a lohùn wí pe : Igba kọpọ akara kò to fun wọn, ki olukuluku wọn iba fi mu diẹ diẹ. Okan ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, Anderu, arakọnri Simoni Piteru wi fun u pe : Ọmọkọnri

kan wà nihinyi, ti o ni isu akara marun àti ẹja kekere meji ; Ṣugbọn kini wọnyi fun ọpọ enia wọnyi? Jesu sì wi pe : ẹ mu awọn enia joko. Koriko pupọ sì wà nibẹ, ati o to iwọn ẹgbẹdọgbọn ọkọuri ti o joko. Jesu sì mu isu akara wọnyi, nigbati a sì ti dupẹ, o pin wọn fun awọn ti o joko, bẹ gẹgẹ sì ni ẹja, niwọn bi nwọn ti nfẹ. Nigbati nwọn je ajẹyó, o wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : Ẹ kó ajẹkùn ti o kùnjọ, ki ohunkohun máṣe ṣegbé. Nwọn sì kó wọn jọ, a sì kún agbọn mejila fun ajẹkùn isu akara marun, ti o ṣikùn lẹhin ti gbogbo wọn je tán. Nitorinâ nigbati awọn enia nâ ri iṣẹ iyanu ti Jesu ṣe, nwọn wipe : Lôtọ eyi ni wòlì nâ ti mbọ wá aiye. Ṣugbọn nigbati Jesu mọ pe nwọn nfẹ wá fi agbara mu on lọ lati fi I jọba, O salọ sori òke on nikan.

Ifitọrẹ. Ẹ yìn Oluwa, nitoriti o ṣeun ; ẹ kọrin iyìn si orukọ rẹ, nitoriti o dùn. Ohunkohun t'o ba wù Ù fi on nṣe l'ọrun ati l'aiye.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi oju ânu wò ẹhọ yi t'a rù si Ọ, ki o lè mu walọ siwaju ninu ìwa bi Ọlọrun, ki o sì lè ri igbalà ainipẹkun gbà fun wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Jerusalemu, iwọ t'a kọ bi ilú t'o faramọra, ọdọ re l'awa nlọ foribalẹ fun Ọlọrun wa ; nitori nibẹ ni awọn èya enia ti Oluwa mâ jumọ goke lọ lati mâ yìn orukọ Oluwa logo.

Adura lẹhin Komunioni.

Olọrun, alànu julọ, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifun ni, k'awa lè fi ibẹru tôtọ bọlá fun sakramenti rẹ mimọ, t'a ma fi bọ wa nigbagbogbo, k'awa sì lè fi ọkàn mimọ ati alaisẹtan gbà a nigbagbogbo; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ TI IJIYÀ OLUWA

Ipilẹsẹ ti Misa. Ṣe idajọ mi Olọrun, k'o sì yà oran mi s'ọtọ kuro ninu ti orilẹ-ede alaimọ. Gbà mi lọwọ alaisodo ati ẹlẹtan, nitori Iwọ ni Olọrun mi ati agbara mi. *Ps.* Rán imọlẹ ati otitọ rẹ jade. Awọn nã l'o ṣe amọna mi, ti nwọn sì mu mi wá sori òke rẹ mimọ, ati sinú awọn agọ rẹ.

Adura.

Olọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ojurere wò awọn enia rẹ, nipa ôre-ọfẹ rẹ ki a lè mâ ṣe akoso wọn li ara, ati nipa âbo rẹ ki a sì lè mâ pa wọn mọ li ọkàn; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Heb. 9.

Ará mi, nigbati Jesu-Kristi wá si aiye lati ṣe olori saserdoti ohun rere ti mbọ, nipa agọ (ara) ti o tobi, ti o sì péjù, ti a kò fi ọwọ enia pa, eyi nipe, kì iṣe ti ẹdá yi, bẹni kì iṣe nipasẹ

èjè ewurè ati òmò malu, ṣugbọn nipa èjè ontikalarè li o ti wòle lèkanṣoṣo sinu ibi mimó yi (òrun rere), o sì ri idánde ainipèkun gbà fun wa. Nitoripe bi èjè ewurè ati ti akọ-malu, ati ibuwón èru egbòrò abo malu ba nsọ awọn alaimó di mimó nipa wiwè wọn nù li ara, melo melo li èjè Jesu-Kristi, eni nipa Emi-Mimó ti o fi ara rè rùbọ si Olòrun lailabawón, yio wè ọkàn wa nù mó kuro ninu okú iṣe (èṣè) lati sìn Olòrun alâye? Ati nitori idi eyi li o ṣe di onilàja majèmu titun, pe nipase ikú ti o kú lati ṣe ètutu fun èṣè ti a da labè majèmu iṣaju, ki awọn ti Olòrun ti pè lè ri ijogún ainipèkun ti o sè ileri fun wọn gbà.

Graduali. Oluwa, gbà mi lọwó awọn ọtá mi; kó mi lati sè ifè rè. Oluwa, Iwọ ti o gbà mi lọwó ibinu awọn ọtá mi, iwọ o gbé mi leke jù awọn ti o dide si mi lọ; iwọ o sì gbà mi l'ọwó ọkọnri buburu ati alaiṣododo.

Traktu. Ki Israeli wi nisisiyi pe: igbakugba ni awọn ọtá mi kọlu mi lati igba ewe mi wá, ṣugbọn nwọn kò ti bori mi. Awọn èlèṣè ti lù mi lèhin bi ogún agbède, nwọn sì mu iwa ikà wọn gun nipa dida ara mi loró. Ṣugbọn olododo li Oluwa, O ṣe awọn èlèṣè l'òrun.

Ihin rere (Jon. 8).

Nigbanà ni Jesu wi fun awọn Ju pe: Tani ninu nyin t'o lè kà èṣè kan si mi l'òrùn? Bi o ba ṣe pe otitọ ni mo wí, èṣe ti enyin kò gbà mi gbó? Eniti ise ti Olòrun, a mà gbó òrò Olòrun. Ṣugbọn enyin kò gbó ọ nitoriti enyin kì

iṣe ti Ọlọrun. Nigbanâ ni awọn Ju dahùn, nwọn si wi fun U pe : Awa kò ha wi otitọ pe: ará Samaria ni iwọ iṣe, ati pe iwọ li èṣu l'ara. Jesu dahùn wipe : Emi kò li èṣu l'ara, ṣugbọn emi mbọlá fun Baba mi, ẹnyin si ṣaibọlá fun mi. Bi o ṣe ti emi ni, emi kì yio wá ọlá emi tikalami ; Eni kan wà ti yio wá a, ti yio si da mi l'âre. Lôtọ, lôtọ ni mo wi fun nyin, bi ẹnikan ba pa ọrọ mi mọ kì yio ri ikú lailai. Nigbanâ ni awọn Ju wí fun U pe : Nigba yi li awa mọ pe iwọ li èṣu l'ara, Abrahamu ati awọn woli kú; Iwọ si wi pe : bi ẹnikan ba pa ọrọ mi mọ, kì yio ri ikú lailai. Iwọ pọ ju Abrahamu baba wa lọ, ẹniti o kú ? ati awọn woli kú. Tani iwọ nfi ara rẹ pè? Jesu dahùn wipe : Bi emi ba mbọlá fun ara mi, asán li ọlá mi. Baba mi ni ẹniti mbọlá fun mi, ẹniti ẹnyin wi pe : Ọlọrun nyin ni iṣe. Sibẹ ẹnyin kò mọ ọ, ṣugbọn bi o ṣe ti emi ni, emi mọ ọ ; bi emi ba si wipe emi kò mọ ọ, emi o jẹ eleke gegẹbi ẹnyin. Ṣugbọn emi mọ ọ, mo si pa ọrọ rẹ mọ. Abrahamu, baba nyin, yọ lati ri ọjọ mi, o ri i, o si yọ. Nigbanâ ni awọn Ju wi fun u pe : Ọdún rẹ kò ti ito adọta, iwọ si li ri Abrahamu? Jesu dahùn wipe : Lôtọ, lôtọ ni mo wi fun nyin, ki Abrahamu to wà, emi ni yi. Nigbanâ ni nwọn gbé okuta soke lati sọ lù u, ṣugbọn Jesu fi ara rẹ pamọ, o si jade kuro ni ile Ọlọrun.

Ifitọrẹ Oluwa, tọkàntọkàn li emi o mâ yìn Ọ, fi òre-ọfẹ yi fun ọmọ-ọdọ rẹ, ki emi ki o lè wà lâye, ki emi si lè pa ofin rẹ mọ. Oluwa, ṣọ mi di alâye gegẹbi ọrọ rẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ yi lè da wa nide kuro ninu ẹwọn ìwa buburu wa, ki o sì lè mu ẹbun ânu rẹ wá sori wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Eyiyi li ara mi ti aofi silẹ fun pipa nitori nyin; kalisi yi ni majẹmu titũn li ẹjẹ mi, ni Oluwa wí, ẹ mà ṣe eyi ni iranti mi, nigbakugba ti ẹnyin ba ngbà ohun wọnyi

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa Olọrun wa, kọn wa lọwọ, ki o sì fi iranlọwọ titilọ ti ôre-ọfẹ rẹ dàbobo awọn ẹniti iwọ sọ di alabapin ninu sakramenti rẹ mimọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ TI IMỌ, TABI MARIWO

Ibukún awọn imọ. Olọrun, mu igbagbọ awọn ti ngbẹkẹle Ọ posi i, ki o sì fi ânu gbọ adura awọn ti nkigbe pè Ọ; jẹ ki ọpọ ânu rẹ ki o sọkalẹ wá sori wa, ki o sì bukún fun awọn mariwo tabi ẹká igi olifi wọnyi; gẹgẹbi iwọ sì ti mu Noe ti o jade kuro ninu ọkọ bi si i li aworan Eklesia rẹ, ati Mose ti o jade lati Egipti wá, bẹni ki o bukún fun awa ti ngbé mariwò ati ẹká igi olifi si ọwọ, ki awa lè fi isẹ rere pade Jesu-Kristi, ki awa sì lè bá A wọ inu ibi ayọ ainipẹkun. Ẹnit'o jẹ Olọrun, ti o wà, ti o

sì jọba pẹlu Iwọ ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Lẹhin orin Sanctus, a kà adura ti o tẹle eyi.

Adura.

Olọrun, Iwọ ti o kó eyiti o túka jọ, Iwọ ti o sì pa eyiti o kó ara rẹ jọ mọ; Iwọ ti o bukún fun awọn enia ti o pade Jesu-Kristi li ọna pẹlu ẹká igi wẹwẹ li owọ́ wọn, bẹni ki o bukún fun mariwò ati ẹká igi olifi wọnyi, ti awọn ara ilẹ rẹ nfi ifọkansìn gbà li ogo orukọ rẹ, ki ibikibi ti a o fi wọn si, ki nwọn lè mu ibukún rẹ wá sori awọn ti ngbé ibẹ; nigbati a sì ti yọ kuro ninu gbogbo ipọnju, jẹ ki owọ́ ọtún rẹ ki o lè mà dàbobo awọn eniti Jesu-Kristi Ọmọ rẹ Oluwa wa ti gbà là. Ẹniti o jẹ Olọrun, ti o wà, ti o sì jọba pẹlu Iwọ ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Adura

Oluwa, Iwọ ti o fi aṣẹ fun àdaba lati fi ẹká igi olifi so alafia fun aiye, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fivesi i lati fi ibukún rẹ orun so ẹká igi olifi ati ti awọn igi miran dì mimọ́, ki nwọn lè ṣe anfani fun igbalà gbogbo awọn enia rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Nigbati a ṣe ipinfun ni imọ, a kọrin eyi pe.

1. Awọn ọmọ Heberu ti o gbé ẹká igi olifi si owọ́, pade Oluwa lọna, nwọn kigbe wipe: Hosanna (ogo) fun Ọ loke orun.

2. Awọn ọmọ Heberu tẹ̀ aṣọ wọn sọ̀na, nwọn sì nkigbe wipe : Hosanna fun ọmọ Dafidi : ibukún ni fun ẹniti mbọ̀ wá li orukọ Oluwa.

Adura.

Olọrun Olodumare, ati aiyeraiye, Iwọ t'o gbé Jesu-Kristi Oluwa wa kà ọmọ kẹtẹkẹtẹ, t'o sì ti kọ́ ijọ awọn enia lati tẹ̀ aṣọ wọn tabi ẹká igi wẹ́wẹ sọ̀na ati lati korin Hosanna si ọlá rẹ̀, fifun ni, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki awa lè topasẹ wọn li ìwa rere, k'awa sì lè yẹ lati ri ère wọn gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ran mi l'ọwọ́, má ṣe jina si mi, fiyesi i lati dâbobo mi ; gbà mi kuro l'ẹnu kiniun, ati ìwa irẹlẹ mi kuro l'ọwọ́ agbanrére. *Ps.* Olọrun mi, Olọrun mi, ṣiju wò mi, èṣe ti iwọ fi k'ọ mi silẹ?

Adura.

Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ t'o fẹ́ ki Olugbala wa nu ara bi tiwa wọ̀, k'o sìjiya ikú lori agbelebu lati fi apẹrẹ irẹlẹ fun araiye, fi ôre-ọfẹ fun wa, ki awa ki o lè yẹ lati topasẹ isùru rẹ̀, ati lati dì a'abapin ninu ajinde rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Fil. 2).

Arâ mi, jẹ ki ironu nyin k'o ri bakannâ bi ti Jesu-Kristi. Ẹni, b'o tilẹ ni àwọ ati ìwa-Olọrun, ti kò kà a si olè lati ba Olọrun dọgba, ṣugbọn o bọ́ ogo rẹ̀ silẹ, o nu àwọ iranṣẹ wọ̀,

a sì da a l'aworan enia, a sì mọ Ọ li enia nipa ode ara rẹ. O rẹ ara rẹ silẹ, o sì tẹriba titi di oju ikú, ani ikú l'ori agbelebu : Nitorinâ ni Ọlọrun ti gbé e leke, o sì ti fi orukọ fun u ti o ta gbogbo orukọ yọ, pe li orukọ Jesu ni ki gbogbo èkun ki o mâ kunlẹ li ọrun li aiye ati li ọrun-apâdi, ki gbogbo ahọn ki o sì mà jẹwọ pe Oluwa Jesu-Kristi wà ninu ogo Ọlọrun Baba.

Graduali. Iwọ l'o dì ọwọ ọtún mi mu, iwọ sì dàri mi gẹgẹbi ifẹ rẹ, iwọ sì gbà mi sinu ogo rẹ. Bi Ọlọrun Israeli ti ṣeun to fun awọn olọkan titọ! Ẹsẹ mi fẹrẹ há riri, ìsisẹ mi fẹrẹ yàna, nitoriti mo jówu si awọn ẹlẹṣẹ, nigbati mo ri alafia awọn enia buburu.

Traktu. Ọlọrun mi, Ọlọrun mi, ṣijuwò mi, èṣe ti iwọ fi kọ mi silẹ? Igbe èṣe mi mu iranlọwọ rẹ jina si mi. Ọlọrun mi, emi nkigbe li ọsán, iwọ kò sì da mi lohùn; emi nkigbe l'oru, iwọ kò sì gbohùn mi, sibẹ a kò kà a bi iwère sì mi l'ọrùn. Iwọ ngbé inu ibi mìmọ, Ọlọrun, iwọ ti ìṣe ogo Israeli. Iwọ ni awọn baba wa gbẹkẹle, iwọ ni nwọn gbẹkẹle, iwọ sì gbà wọn silẹ. Nwọn kigbe pè ọ, a sì gbà wọn là, nwọn gbẹkẹle ọ, nwọn kò sì dâmu. Bi o ṣe ti emi ni, kòkoro li emi, kì ìṣe enia ; àni emi ni ẹgàn ati ẹlẹya awọn enia. Gbogbo awọn ti o ri mi, nyọsùti si mi, nwọn nsọrọ si mi, nwọn sì nmì orí wọn wipe : O gbẹkẹle Ọlọrun, jẹ ki Oluwa gbà a silẹ, ki o sì gbà a là, nitoriti o fẹ E. Ṣugbọn nwọn tẹjumọ mi, nwọn sì wò mi yika. Nwọn pín aṣọ mi fun ara wọn, nwọn sì nṣẹ gegé le aṣọ-ìleke mi. Gbà mi kuro l'ẹnukiniun,

ati ìwa-irelẹ mi kuro ninu íwo agbanrère. Ẹnyin ti o bèru Oluwa, ẹ yìn I; gbogbo ẹnyin irú-ọmọ Jakọbu, ẹ yìn I logo. Nwọn o mâ sọrọ Oluwa fun awọn enia ti o mbọ wá; awọn ọrun sì mâ rohin ododo rẹ fun awọn enia ti ao bí, ti Oluwa ti dá.

Itan ijiyà Oluwa wa Jesu-Kristi.

(Nipati Mat. 26-28).

Nigbanà ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe: Ẹnyin mọ pe lẹhin ọjọ meji ni ijọ Paska (irekọja), ao sì fi Ọmọ-Enia hàn fun ni lati kàn a mọ agbelebu. Nigbanà ni awọn olori alufa ati awọn alàgba enia pejọ li afin olori alufa, eniti a npè ni Kaifa, nwọn sì gbimọ bi nwọn iba ti fi ẹtan mu Jesu, ki nwọn ki o pa a. Ṣugbọn nwọn wí pe: kì ise l'ijọ ọdún, ki irọkẹkẹ ki o má ba wà ninu awọn enia. Nigbati Jesu sì wà ni Betani ni ile Simoni adẹtẹ, nibẹ ni obiri kan wá sodọ rẹ pẹlu kólobo alabasta ti o kún fun ikunra iyebiye, o sì ndà a si I lori, bi o ti joko ti onjẹ. Nigbati awọn ọmọẹhin rẹ sì ri i, inu wọn rú, nwọn wi pe, nitoriti kili a ṣe nfi eyi ṣòfo? A ba tà ikunra yi li owo iyebiye, a ba sì fifun awọn talakà. Ṣugbọn Jesu ti o mọ iròmu wọn, wí fun wọn pe: Ẹse ti ẹnyin fi nyọ obiri nà l'ẹnu? Nitori iṣẹ rere li o ṣe si mi lara. Nigba gbogbo li ẹnyin sá ni talakà pẹlu nyin; ṣugbọn ẹnyin kò ni mi nigbagbogbo. Nitori li eyi ti obiri yi dà ikunra yi si mi lara, o ṣe e fun sisinkú mi. Lótọ ni mo wí fun nyin, nibikibi ti ao wasu Ihin rere

yi ni gbogbo aiye, nibẹ̀ pẹlu li a o sì ròhin eyiti obiri yi ṣe lati fi ṣe iranti rẹ̀. Nigbanâ ni ọkan ninu awọn mejejila, t'a npè ni Juda Iskariotu, tọ̀ awọn olori alufa lọ. o sì wí fun wọn pe: Kili enyin o fi fun mi, emi o sì fi I le nyin lọwọ́? Nwọn ba a ṣe adehùn ọgbọ̀n owo fadaka. Lati igbanâ lọ li o ti nwá ọ̀na lati fi I le wọn lọwọ́. Nigba ọjọ́ kini ọdún aiwukara, awọn ọmọ-ẹhin tọ Jesu wá, nwọn sì wí fun U pe: Nibo ni Iwọ nfẹ́ k'a pèse ọdọ-agutan Irekọja silẹ fun O lati jẹ? Ṣugbọn Jesu da wọn lohùn wipe: Ẹ wọ̀ ilú lọ sọdọ ọkọnri kan bai, ki enyin sì wí fun u pe: Olukọni wipe: Akokò mi nsunmọ́ etile, emi o ṣe ọdún Irekọja ni ile rẹ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin mi. Awọn ọmọ-ẹhin nâ sì ṣe gẹgẹ bi Jesu ti fi aṣẹ fun wọn; nwọn sì pèse ọdọ-agutan Irekọja silẹ. Nigbati alẹ sì lẹ́. O joko ti onjẹ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ mejila. Bi nwọn sì ti njẹun, O wí fun wọn pe: Lôtọ ni mo wí fun nyin, ọkan ninu nyin yio fi mi hàn. Nigbanâ ni inu wọn bajẹ gidigidi, olukuluku wọn sì bẹ̀rẹ si bi I lère pe: Oluwa, iṣe emi bi? Ṣugbọn O da wọn lohùn wipe: Eniti o ba mi tọwọ́ bọ̀ inu awo, on nâ ni yio fi mi hàn. Bi o ṣe ti Ọmọ-enia ni, o nlọ bi a ti kọwe nipa tirẹ̀; sugbọn egbé ni fun ọkọnri nâ lati ọwọ́ eniti ao fi Ọmọ-enia hàn: iba san fun ọkọnri nâ, bi o ṣepe a kò bí i. Ṣugbọn Juda, t'o fi I hàn dahùn wipe: Oluwa, iṣe emi ni bi? O wí fun u pe: Iwọ wí i. Bi nwọn sì ti njẹ onjẹ alẹ, Jesu mu akara o sure si i, o sì bù, o sì fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o wipe: Ẹ gbà, k'ẹ sì jẹ, eyiyi li ara mi. O sì mu kalisi, o dupẹ, o sì fifun wọn, o wipe: Gbogbo nyin ẹ mu ninu

rẹ ; nitoripe eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titún, eyiti ao tasilẹ fun ọ̀pọ enia nitori imukuro ẹ̀ṣẹ. Sugbọn mo wi fun nyin, lati isisiyi lọ emi kì yio mu ninu eso ajara yi mọ́, titi yio fi di ọjọ́ nâ ti emi o tún bá nyin mu u ni ijọba Baba mi. Nigbati nwọn sì kọ orin kan tán, nwọn jade lọ sori òke Ólifi. Nigbanâ ni Jesu wí fun wọn pe : Li oru yi li ao mu gbogbo nyin dẹṣẹ nitori mi ; nitoriti a ti kọwe rẹ̀ pe : Èmi o lù olusọ-agutan, ao sì tú agbo agutan nà ká kiri ; sugbọn lẹhin igbati mo ba tún jinde, emi o ṣaju nyin lọ si Galili. Nigbanâ ni Piteru dahùn, o sì wí fun u pe : Bi a tilẹ mu gbogbo enia dẹṣẹ nitori rẹ, lai a kì yio mu mi dẹṣẹ. Jesu sì wí fun u pe : Lõtọ ni mo wí fun ọ pe : Li oru yi ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ mi nigba mẹta, Piteru wí fun u pe : Bi o tilẹ di ati bá ọ kú, emi kì yio sẹ ọ. Gẹgẹ bẹ̀ni gbogbo awọn ọmọ-ẹhin iyokùn sì wí pẹlu Nigbanâ ni Jesu bá wọn wá sibi kan ti a npè ni Getsemani, O sì wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ẹ joko nihinyi nigbati mo ba lọ gbadua lọhúnyi. O sì mu Piteru ati awọn ọmọ Sebede mejeji pẹlu rẹ̀, o sì bẹ̀rẹsi mâ kânu, o sì fajuro. Nigbanâ ni o wí fun wọn pe : Ọkàn mi nkânu gidigidi ani titi de oju ikú. Ẹ duro nihinyi, ki ẹ sì mâ bá mi ṣọna. O sì lọ siwaju die, o doju bọlẹ, O sì ngbadura wipe : Baba mi, bi o ba lè ṣe, jẹ ki kalisi yi ki o koja kuro l'ori mi, sugbọn ki imá ṣe bi emi ti nfẹ́, bikoṣe, bi Iwọ ti fẹ́. O sì tọ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wá, o ba wọn, nwọn nsûn, o sì wí fun Piteru pe : Kinla! Ẹnyin kò lè ba mi ṣọna ni wakati kan? Ẹ mâ ṣọna, kí ẹnyin ki o sì ma gb'adura, ki ẹnyin ki o má ba

ṣubu sinu idanwò. Lôtọ li ẹmí nfé, ṣugbọn o ṣe alailera fun ara. O sì tún pada lọ lârin keji, o sì ngdadua wipe : Baba mi, bi kalisi yi kò ba lè kọja lọ, bikoṣe pe mo mu u, ifé tirẹ, ni ki a ṣe. O sì wá, o sì tún ba wọn, nwọn nsùn, nitori ti oju wọn kún fun orun ; o sì fi wọn silẹ, o tún pada lọ, o sì ngbadua lârin kẹta, o nsọ ọrọ kannâ. Nigbanâ li o tọ awọn ọmọ-ẹhin rẹ wá, o sì wí fun wọn pe : Ẹ ma sùn wayi, ki ẹnyin sì ma simi : kiyesi i, wakati kùn si dẹdẹ, ti ao fi Ọmọ-enia le awọn ẹlẹṣẹ lọwọ. Ẹ dide, ki a ma lọ ! wò o, eniti o fi mi hàn sunmọ tosí. Bi O sì ti nsọ lọwọ, wò o, Juda, ọkan ninu awọn mejejila de, ati pẹlu rẹ, ọpọ enia ti awọn ti idà pẹlu ọgọ, ti a rán lati ọdọ awọn olori alufa ati awọn alàgba enia wá. Eni ti o sì fi I hàn fi àmi fun wọn wipe : Enikẹni ti mo ba fi ẹnu kó li ẹnu, on nâ ni ; ki ẹnyin ki o mu u girigiri. Lojukannâ o wá sọdọ Jesu, o sì wipe : Alafia Olukọni, o sì fi ẹnu kó ol'ẹnu. Jesu sì wí fun u pe : Ọrẹ, èṣe ti iwọ fi wá ihinyi? Nigbanâ ni nwọn wá, nwọn sì gbé ọwọ le Jesu, nwọn sì mu U. Si wò o ọkan ninu awọn t'o wà pẹlu Jesu nà ọwọ rẹ, o fà idà rẹ yọ, o sì sa iransẹ olori alufa, o sì ke e li etí sọnù. Nigbanâ ni Jesu wí fun u pe : Fi idà rẹ sinu ipò rẹ ; nitoripe gbogbo awọn ti o mu idà ni yio ti ipa idà ṣegbé. Iwọ há ṣebi emi kò lè kepè Baba mi, on iba sì fun mi jù ogun awọn Angẹli mejila lọ lojukannâ yi bi ? Ṣugbọn bawo li ọrọ iwe mimọ yio ha ti ṣe ṣẹ, eyiti o wipe, bẹni yio ri ? Ni wakati nà ni Jesu wí fun ijọ enia pe : Emi li ẹnyin jade tọ wá bi olè, ti ẹnyin ti idà ati ọgọ lati mu. Lojojumọ li emi mbá nyin

joko, ti mo sì nkọ́ nyin ni tempeli (ile Ọlọrun), ẹnyin kò sì gbé ọwọ́ le mi. Ṣugbọn gbogbo eyi ṣẹ, ki Iwe mimọ́ ti awọn woli ki o lè ṣẹ. Nigbanà ni gbogbo awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ fi i silẹ, nwọn sì sá lọ. Ṣugbọn awọn ti o gbà Jesu mu, fà a lọ sodọ̀ Kaifa, olori awọn alufa, nibiti awọn akọwe ati awọn alàgba gbé pejọ̀ si. Ṣugbọn Piteru tọ̀ ọ lẹhin li òkere titi fi de agbalà olori awọn alufa, o sì wọle, o sì bá awọn onisẹ nâ joko lati ri opin rẹ̀. Nigbanâ li awọn olori alufa ati gbogbo ijọ igbimọ̀ nwá ẹrí eke si Jesu lati pa a; nwọn kò sì ri ohun kan, bi o ti je pe ọ̀pọ ẹlẹ̀ri eke dide wá. Nikẹhin li awọn ẹlẹ̀ri eke meji wá, nwọn wipe: Ọkọnri yi wipe: Emi lè wó tempeli Ọlọrun, emi sì lè tún kọ́ ọ ni ijọ́ meta. Nigbanà ni olori awọn alufa dide, o sì wí fun u pe: Iwọ kò dahùn kan si eyiti awọn wọnyi njẹri si ọ? Ṣugbọn Jesu dakẹ. Olori awọn alufa sì wí fun u pe: Li orukọ Ọlọrun alâye ni mo fi ọ bura pe ki iwọ ki o sọ fun wa bi iwọ ba ṣe Kristi, Ọmọ Ọlọrun. Jesu wí fun u pe: Iwọ wí i; ṣugbọn mo wí fun nyin pe li ojọ́ kan ẹnyin o ri Ọmọ enia ti yio joko lọwọ́ ọtún ọlá nla Ọlọrun, ti yio sì nia wá lori awọ-sanma ọrun. Nigbannâ ni olori awọn alufa fà aṣọ rẹ̀ ya, o wipe: O sọ òrọ odi si Ọlọrun! Ẹlẹ̀ri kili a sì nwá? Wò o, ẹnyin gbọ́ òrọ odi si Ọlọrun nisisiyi. Kili ẹnyin rò si i? Nwọn dahùn wipe: O jẹbi ikú. Nigbanà ni nwọn tutọ́ si I loju, nwọn kàn A l'ẹṣẹ́; Awọn ẹlomiran sì fi atẹlẹ ọwọ́ wọn gbá A l'oju, nwọn wipe: Sọ tẹlẹ fun wa, Iwọ Kristi, tani ẹniti o nlù Ọ ni? Ṣugbọn Piteru joko lode li afin, ọmọ ọdọbiri kan sì tọ̀ ọ wá, o wipe: Iwọ

ti wà pẹlu Jesu ti Galili. Ṣugbọn o sẹ loju gbogbo wọn : o wipe : Emi kò mọ ohun ti iwọ wí. Bi o sì ti jade lọ si iloro, ọmọ-ọdọ biri miran sì ri i, o sì wí fun awọn t'o wà nibẹ pe: Ọkọnri yi ti wà pẹlu Jesu ti Nasareti. O sì tún fi èpe sẹ wipe : Emi kò mọ ọkọnri nà. Nigbat'o pẹ diẹ, awọn t'o duro nibẹ tọ ọ wá, nwọn wí fun Piteru pe : Lôtọ, ọkan ninu wọn ni iwọ nṣe; nitoripe ède rẹ fi ọ hàn. Nigbanà ni o bẹrẹ si fi ara rẹ bu, o sì mbura wipe : Emi kò mọ ọkọnri nà. Lojukannà akukọ sì kọ. Piteru sì ranti ọrọ ti Jesu wí fun u pe : Ki akukọ ki o to kọ, iwọ o sẹ mi lârin mẹta. O sì bọ s'ode, o sọkun gidigidi. Nigbat'o di owurọ, gbogbo awọn olori alufa ati awọn alàgba enia gbimọ si Jesu lati pa A. Nigbati awọn sì dè E tán, nwọn mu U lọ, nwọn sì fi I le Pontiu Pilatu lọwọ ti iṣe bãlẹ. Nigbanà ni Juda, ẹni t'o fi I hàn, nigbat'o ri pe, a da A lẹbi ikú o ronupiwada o sì mu ọgbọ̀n owo fadaka pada wá ọdọ awọn olori alufa ati awọn alàgba, wipe : emi ṣẹ li eyiti mo fi èjẹ alaiṣẹ hàn. Nwọn sì wipe : Kini eyini si wa? Mâ bojuto eyi ni. O sì da owo fadaka nâ silẹ ni tempeli, o sì jade, o sì lọ so ara rẹ. Ṣugbọn awọn olori alufa mu owo fadaka nà, nwọn sì wipe : Kò tọ ki a fi i sinu iṣura tempeli, nitoripe iye owo èjẹ ni. Nigbati nwọn sì gbimọ, nwọn fi rà ilẹ amọkoko, lati mâ sinkú awọn alejò ninu rẹ. Nitorinà ni a ṣe npè ilẹ nâ ni Haseldama, eyi ni ilẹ èjẹ, titi o fi di ọjọ oni. Nigbanà li ọrọ ti Jeremia woli sọ wá ṣẹ, pe : Nwọn sì mu ọgbọ̀n owo fadaka, iye owo ẹniti a diyelé, ẹniti awọn ọmọ Israeli diyelé, nwọn sì fi rà ilẹ amọkoko,

gẹgẹbi Oluwa ti làna silẹ fun mi. Jesu sì duro niwaju Bâlẹ; Bâlẹ sì bi i lère, wipe: Iwọ li ọba awọn Ju? Jesu wí fun u pe: Iwọ wí i. Nigbati a sì sọn u l'ẹsọn lati ọwọ awọn olori alufa ati awọn alàgba wá, on kò dahùn kan, Nigbanà ni Pilatu wí fun u pe: Iwọ kò gbọ ọpọ ohun ti nwọn njẹri si ọ? On kò sì da a ni gbolohùn kan, tobẹ ti ẹnu ya Bâlẹ gidigidi. Nigba ijọ ọdún nla nâ, Bâlẹ a ti mâ da ondè kan silẹ fun awọn enia, ẹnikẹni ti nwọn ba fẹ. O ni ondè buburu kan lakokò nâ, ti a npè ni Baraba. Nitorinâ nigbati nwọn pejọ, Pilatu wí fun wọn pe: Tali ẹnyin nfẹ ki emi dá silẹ fun nyin? Baraba tabi Jesu ti a npè ni Kristi? O sá ti mọ pe nitori ilara ni nwọn ṣe fi i le on lọwọ. Nigbati o sì joko lori itẹ idajọ, aya rẹ ranṣẹ si i, wipe: Máṣe lọwọ ninu ohun ti ọkọnri olododo ni; nitori ohun pupọ ni mo ri li oju alá l'oni nitori rẹ. Ṣugbọn awọn olori alufa ati awọn alàgba yí ijọ enia l'ọkàn pada si ati bère Baraba, ki o sì pa Jesu. Bâlẹ dahùn, o sì wí fun wọn pe: Ninu awọn mejeji, ewo l'ẹnyin nfẹ ki emi da silẹ fun nyin? Nwọn wipe: Baraba. Pilatu wí fun wọn pe: Kili emi o ha ṣe si Jesu, ẹniti a npè ni Kristi! Gbogbo wọn kigbe wipe: Jẹ ki a kàn a mọ agbelebu! Pilatu wí fun wọn pe: Buburu kili o ṣe? Ṣugbọn nwọn kigbe soke si i pe: Jẹ ki a kàn a mọ agbelebu! Nigbati Pilatu sì ri pe on kò lè bori li ohunkohun, ṣugbọn pe ariwo npọ si i, o bu omi, o sì wẹ ọwọ rẹ l'oju ijọ, o wípe: Orùn mi mọ nipa ẹjẹ enia olotọ yi: Ẹ kiyesi i! Gbogbo enia sì dahùn wipe: Ki ẹjẹ rẹ wà li ori wa, ati li ori awọn ọmọ wa. Nigbanà li o

da Baraba silẹ fun wọn. Nigbati a sì nâ Jesu tán, o fà a le wọn l'ọwọ́ lati kàn a mọ́ agbelebu. Nigbanâ ni awọn ọmọ-ogun Bâlẹ mu Jesu lọ sinu ile ejọ́, nwọn sì kó gbogbo awọn ọmọ-ogun tì I. Nwọn sì bọ Ọ l'aṣọ rẹ̀, nwọn sì wọ̀ ọ l'aṣọ igunwa ododo, nwọn sì wùn adé egún kan, nwọn sì fi de E l'ori, nwọn sì fi ọpá iye le E l'ọwọ́ ọtún; nwọn sì kunlẹ niwaju rẹ̀, nwọn sì nsin I jẹ wipe: Alafia, ọba awọn Ju! Nwọn sì tutọ́ si I lara, nwọn sì gbá ọpá iye nâ, nwọn sì fi lù U l'ori. Nigbati nwọn sì sin I jẹ tán, nwọn bọ aṣọ igunwa nâ kuro lara rẹ̀, nwọn fi aṣọ rẹ̀ wọ Ọ, nwọn sì mu U jade lọ lati kàn a mọ́ agbelebu. Bi nwọn sì ti jade, nwọn ri ọkọnrin kan ará Sirene, ti njẹ Simoni; on ni nwọn fi agbara mu lati rù agbelebu rẹ̀. Nigbati nwọn de ibi ti a npè ni Golgota, eyini nipe, Ibi agbari (Kalfari), nwọn fi ọti vini ti a dâpọ mọ́ orôro fun u lati mu; nigbati o sì tọ́ ọ wò, kò fẹ mu u. Nigbati nwọn sì kàn a mọ́ agbelebu, nwọn pín aṣọ rẹ̀, nwọn sì ṣẹ́ gegé le e, ki eyi ti wolí wí ba le ṣẹ, pe: Nwọn pín aṣọ mi fun ara wọn, aṣọ ileke mi ni nwọn ṣẹ́ gegé le. Nwọn sì joko, nwọn nṣọ́ ọ. Nwọn sì fi òrun ikú rẹ̀ ti a ko si igberi rẹ̀: Eyi ni Jesu, Ọba awọn Ju. Nigbanâ li a kàn awọn olè meji mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀, ọkan li ọwọ́ ọtún, ati ekeji li ọwọ́ òsin. Awọn ti o sì koja lọ mbú u, nwọn sì nmì ori wọn, wipe: Iwọ ti o wó tempeli, ti o sì tún kọ́ ọ ni ijọ́ meta, gbà ara rẹ là; bi iwọ iba ṣe Ọmọ Ọlọrun, sọkalẹ lati ori agbelebu wá. Gegẹ bẹ́li awọn olori alufa pẹlu awọn akọwe ati awọn alàgba nfi ṣe ẹlẹya, wipe: O ngbà awọn ẹlomiran là; on tikalarẹ̀ ni kò

lè gbalà. Bi iba ṣe ọba Israeli, jẹ ki o sọkalẹ lati ori agbelebu wá nisisiyi, awa o si gbà a gbọ́. O gbẹ̀kẹle Ọlọrun ; ẹ jẹ ki o gbà a là nisisiyi, bi o ba fẹ ẹ ; nitoriti o wipe : Ọmọ Ọlọrun li emi. Awọn olè ti a kàn mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀ si nfi eyi gún u lọju bakannâ. Lati wakati kẹfa titi o fi di wakati kẹsan ni òkunkun sú bò gbogbo ilẹ aiye. Nigba wakati kẹsan ni Jesu si kigbe soke li ohùn rara wipe : Eli, Eli, lama sabaktani (eyini ni pe) Ọlọrun mi, Ọlọrun mi ẽṣe ti Iwọ fi kọ̀ mi silẹ ? Nigbati awọn ọkan ninu awọn t'o duro nibẹ̀ gbọ́ eyi, nwọn wipe : Ọkọnri yi npè Eliasi. Lojukannâ ọkan ninu wọn sì sare, o mu sponji (ohun iwẹ̀ju), o tẹ̀ ẹ bọ́ inu oti kikan, o fi le ori ọpá iye, o si fifun U mu. Ṣugbọn awọn iyokù wipe : Ẹ jọwọ́ rẹ̀ si, ẹ jẹ ki a ma wò o bi Eliasi yio wá gbà A là. Jesu si túnkigbe l'ohùn rara, o si jọwọ́ emi rẹ̀ lọwọ́ (*nibi a kunlẹ*). Si wò o, aṣọ ikele ti tempeli fà ya ni meji lati òke de isalẹ ; ilẹ mi-titi, okuta si san ; isà okú ṣí silẹ, òpọ okú ninu awọn eni mimọ́ t'o ti sùn si jinde ; nwọn ti inu isà okú wọn jade lẹhin ajinde rẹ̀, nwọn si wá si ilú mimọ́, nwọn fi ara hàn òpọlọpọ enia. Nigbati balogun ọrún, ati awọn t'o ti wá pẹlu rẹ̀, ti nwọn nṣọ́ Jesu, ri isẹlẹ nâ ati ohun wọnyi t'a ṣe, èru ba wọn gidigidi. nwọn si wipe : Lõtọ, Ọmọ Ọlọrun li eyi ise. Awọn obiri pupọ̀ t'o wà nibẹ̀ pẹlu ti r wọn ngbé okere wò, awọn ti o ba Jesu ti Galili wá lati ṣe iranṣẹ fun U. Ninu awọn eniti Maria Magdalene wà, ati Maria iyá Jakọbu ati Josefu, ati iyá awọn ọmọ Sebede. Nigbati alẹ lẹ tán, ọkunri kan ọlọrọ̀ ará Arimatea wá ibẹ̀, t'a npè ni Josefu,

ẹniti ontikalarẹ̀ iṣe ọmọ-ẹhin Jesu pẹlu. O tọ̀ Pilatu lọ, o sì tọrọ okú Jesu. Nigbanâ ni Pilatu paṣẹ k'a fi okú nâ fun u. Josefu gbé okú nâ, o fi aṣọ ọgbọ mimọ́ dì I, o sì tẹ̀ E sinu ibojì titún ti ontikalarẹ̀, eyiti a wò ninu apata; o yi okuta nla dì ẹnu ọ̀na ibojì nâ, o sì ba tirẹ̀ lọ.

Maria Magdalene ati Maria keji sì wà nibẹ̀, nwọn sì joko li apa etí ibojì nâ. Nigbati o di ọjọ́ keji, eyiti o tẹle ọjọ́ ipalẹmọ́, awọn olori alufa ati awọn Farisi wá pejọ lọdọ Pilatu, nwọn wipe: Àlàgba, awa ranti pe ẹlẹtan ni wí, nigbati o wà làye pe: Lẹhin ijọ́ mẹta, emi o tún jinde! Nitorinâ paṣẹ ki a ṣọ́ ibojì nâ titi yio fi di ijọ́ kẹta, ki awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ máṣe wá li oru lati ji i gbé lọ, ki nwọn má sì wí fun awọn enia pe: O jinde kuro ninu okú, bẹ̀ni iṣìna ikẹhin yio sì buru jù ti iṣaju lọ. Pilatu wí fun wọn pe: Ẹnyin li oluṣọ́, ẹ lọ, ki ẹ sì ṣọ́ bi ẹ ti fẹ́. Bẹ̀ni nwọn lọ, nwọn sì fi oluṣọ́ ṣọ́ ibojì nâ, nwọn sì sàmi sara okuta nâ.

Ifitọrẹ. Okàn mi duro de ẹgan ati osì; emi sì woye ẹniti yio ṣânu fun mi, ṣugbọn kò si, mo wá olutunu, emi kò sì ri ẹnikan. Nwọn sì fi orôro fun mi li ohun jijẹ; ati li ongbẹ mi nwọn fun mi li ọti kikan lati mu.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ ti a rù siwaju Ọlá nla rẹ, ki o lè ri òre-ọfẹ́ ìwa-bi Ọlọrun gbà fun wa, ki o sì lè mu alafia ainipẹkun wá tun wa; nipaṣẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin

Komunioni. Baba mi, bi kalisi ijiyà yi kò ba lè kọja lọ bikoṣe pe emi mu u, ifẹ ti rẹ ni ki a ṣe.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, fifuni, nipa agbara sakramenti yi ki a lè wẹ wa nù kuro ninu èṣẹ wa, ki a sì lè mu ifẹ titọ wa ṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

TURSDAY LI ỌSẸ MIMỌ

Ipilẹṣẹ ti Misa. O tọ ki awa ṣogo ninu agbelebu Jesu-Kristi, Oluwa wa, l'ọdọ eniti a ri igbalà, ìye ati ajinde wa; nipasẹ eniti a gbà wa là, t'a sì da wa nide. *Ps.* Ki Ọlọrun ki o ṣãnu fun wa, ki o sì bukún fun wa; ki o ṣe oju rẹ ki o mọlẹ si wa l'ara, ki o sì fi ãnu rẹ hàn wa.

Adura.

Ọlọrun, l'ọwọ eniti Juda ti ri ijiyà èṣẹ rẹ gbà ati olè èrè ijẹwọ rẹ, fifun ni ki awa lè mọ agbara ilaja re pe, gẹgẹ bi ninu ijiyà rẹ Jesu-Kristi Oluwa wa ti fun awọn mejeji li èrè itoye ti o yatọ, bẹni ki a lè gbà wa kuro ninu iṣina ati èṣẹ t'igbanì, ki awa lè ri ôre-ọfẹ ajinde rẹ gbà; eniti'o wà, t'o sì jọba pẹlu Iwọ, ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ lai, Ọlọrun kan aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (1 Kor. 11).

Ará mi, nigbati ẹnyin ba pejọpọ̀ si ibi kan, eyi kì ise lati jẹ onjẹ alẹ Oluwa mọ́, nitoripe olukuluku nyin ngbà onjẹ tirẹ̀ ṣaju ẹnikeji, bẹ̀ni ebi npa ẹnikan, ẹnikeji sì nmu amupara. Ẹnyin kò ha ni ile, nibiti ẹnyin o mâ jẹ, ti ẹnyin o sì mâ mu bi? Tabi ẹnyin ngàn ijọ enia Ọlọrun, ẹnyin sì ndoju ti awọn ti kò ni nkan kan? Kili emi o wí fun nyin? Emi o ha yìn nyin ninu eyi? Agbẹdọ, emi kò yìn nyin rara. Nitoripe l'ọwọ́ Ọlọrun ni mo ti gbà eyini ti mo ti fifun nyin pẹlu pe, Oluwa Jesu l'oru ọjọ́ nâ t'a ṣofofo rẹ̀, O mu akara, O dupẹ, O sì bu, O sì wipe: Ẹ gbà, ẹ sì jẹ, eyiyi li ara mi, ti ao fi fun pipa nitori nyin; ẹ mâ ṣe eyi ~~ti iranti~~ mi. Gẹgẹ bẹ̀ pẹlu o sì mu kalisi, lẹhin igbati o jeun tán o nwipe: Kalisi yi ni majẹmu titún li ẹ̀jẹ mi; nigbakugba ti ẹnyin ba nmu u, e mâ ṣe eyi ni iranti mi. Nitoriti nigbakugba ti ẹnyin ba njẹ akara yi, ti ẹnyin ba sì nmu kalisi yi, ẹnyin yio fi ikú Oluwa hàn titi yio fi de. Nitorinâ ẹnikẹni ti o ba jẹ akara yi, tabi ti o ba mu kalisi Oluwa yi laiyẹ, on o jẹbi *ibajẹ* ara ati ẹ̀jẹ Oluwa. Njẹ nitorinâ ki enia ki o wadi ara rẹ̀ daju, bẹ̀ni ki o sì jẹ ninu akara nâ, ki o sì mu ninu kalisi nâ, nitoripe ẹnikẹni ti o ba njẹ *akara nâ*, ti o ba sì nmu *kalisi nâ* laiyẹ, o njẹ, o sì nmu ẹbi fun ara rẹ̀, nitoriti kò mọ̀ iyatọ ara Oluwa. Nitori idi eyi li ọ̀pọ̀lọpọ̀ fi dì alailéra, ati olokunrun ninu nyin, ti ọ̀pọ̀lọpọ̀ sì sùn *orun ikú*. Ṣugbọn bi awa ba da ara wa lejọ, a kì yio da wa lejọ. Nigbati a ba sì nda wa lejọ, lati ọwọ́ Oluwa li a ti n-nâ wa, ki a máṣe da wa lẹbi pẹlu aiye yi.

Graduali. Jesu-Kristi tẹriba nitori wa titidi oju ikú, ani ikú agbelebu. Nitorinà ni Olọrun ti gbé e leke, o sì ti fi orukọ fun u ti o ta gbogbo orukọ yọ.

Ihin rere (Joh. 13).

Ki ijó ọdún irekọja ki o to de, bi Jesu ti mọ pe wakati rẹ de lati ti aiye yi kuro lọ sọdọ Baba: bi o sì ti fẹ awọn tirẹ ti o wà li aiye yi, o fẹ wọn titi de opin. Nigbati onjẹ alẹ sì pari tán, ti èṣu ti fi i si aiya Judā Iskariotu ọmọ Simoni, lati fi i hàn; bi Jesu tilẹ mọ pe Baba ti fi ohun gbogbo le on l'ọwọ́, ati pe l'ọdọ Olọrun li on ti jade wá, on sì npada lọ sọdọ Olọrun, o dide ni idi onjẹ alẹ, o sì fi agbada rẹ̀ lelẹ̀ l'apakan, o sì mu gèle, o di ara rẹ̀ li amure. Lẹhin eyini o bu omi sinu awo koto kan, o sì bẹrẹsi ima wẹ̀ ẹsẹ awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o sì nfi gèle ti o fi dì amure nù wọn. Nigbanà li o de ọdọ Simoni Piteru; Piteru sì wí fun u pe: Kinla! Oluwa, Iwọ nfẹ̀ wẹ̀ mi li ẹsẹ̀! Jesu dahùn, o sì wí fun u pe: Ohun ti emi nṣe iwọ kò mọ̀ nisisiyi, ṣugbọn iwọ o mọ̀ nikẹhin. Piteru wí fun u pe: Lai Iwọ kì yio wẹ̀ mi li ẹsẹ̀. Jesu da a l'ohùn pe: Bi emi kò ba wẹ̀ ẹ, iwọ kì yio ni ipa l'ọdọ mi Simoni. Piteru sì wí fun u pe: Kì iṣe kiki ẹsẹ̀ mi nikan, ṣugbọn ọwọ́ ati ori mi pẹlu. Jesu wí fun u pe: Eniti a ti wẹ̀ kò tún fẹ́ jù ki a wẹ̀ ẹsẹ̀ rẹ̀, o sì mọ́ nibigbogbo. Ẹnyin ti mọ́, ṣugbọn kì iṣe gbogbo nyin. Nitoriti o ti mọ̀ ẹniti yio fi i hàn; nitorinà li o ṣe wí pe: Kì iṣe gbogbo nyin li o mọ́. Nitorinà lẹhin igbati o wẹ̀ wọn tán, ti o sì tún mu aṣọ rẹ̀ wọ̀, o

tún joko ti tabili, o sì wí fun wọn pe: Ẹnyin ha mọ ohun ti mo ti ṣe si nyin? Ẹnyin npè mi ni Olukọni ati Oluwa, ẹnyin sì wí rere, nitori bẹni mo jasi. Nje, bi emi ti iṣe Oluwa ati Olukọni nyin ba nwẹ ẹsẹ nyin o tọ ki ẹnyin pẹlu sì ma wẹ ẹsẹ ara nyin, nitoriti emi fi apẹrẹ fun nyin, ki ẹnyin ki o lè mâ ṣe gẹgẹ bi mo ti ṣe si nyin.

Ifitọrẹ. Ọwọ ọtún Oluwa l'o ṣe iṣẹ iyanu; ọwọ ọtún Oluwa sì gbé mi ga. Emi ki yio kú, bikoṣe yiyè; emi o sì mâ rohin iṣẹ Oluwa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, Baba mimọ julọ, Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, fifun ni, ki on nâ ṣọ ẹbọ wa di atewọgba fun Ọ, ẹnit'o tipa ẹkọ atọwọdọwọ t'oni yi fihàn awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe, ki a mâ ṣe eyini li iranti on, Jesu-Kristi, Ọmọ rẹ, Oluwa wa, ẹniti o jẹ Olọrun, ti o wà, ti o sì jọba pẹlu Iwọ ninu iṣọkan ti Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin

Komunioni. Nigbati Oluwa Jesu ba awọn ọmọ-ẹhin rẹ jẹ onje alẹ tán, O wẹ wọn li ẹsẹ, o sì wí fun wọn pe: Ẹnyin ha mọ ohun ti emi Oluwa ati Olukọni ti ṣe si nyin? Apẹrẹ li emi fifun nyin, ki ẹnyin sì mâ ṣe bẹ gẹgẹ pẹlu.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Olọrun wa, awa mbẹbẹ l'ọdọ rẹ, fifun ni ki awa t'a fi onje iye bọ, lè tipa ẹbun aikú rẹ, ri ohun nâ ti awa nṣe li igba ọjọ aiye wa gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

FRIDAY RERE LI ỌSẸ MIMỌ

Itan ijiyà ti J.-K. nipa Johanu (18-19).

Nigbanà ni Jesu jade pẹlu awọn ọmọ-ẹhin lọ soke odo Kedroni, nibiti ọgba kan wà, ninu eyiti owọ ti on ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀. Juda, ẹnit'o fi i hàn, sì ti mọ̀ ibẹ̀ pẹlu, nitori nigbakugba ni Jesu ima lọ si sibẹ pẹlu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀. Nigbanà ni Juda, ẹnit'o ti gbà ọwọ ọmọ ogun, ati awọn iranṣẹ lati ọdọ awọn olori alufa ati awọn Farisi, wá sibẹ̀, ti awọn ti fitila, ati igi inà pẹlu ihamọra. Ṣugbọn Jesu ẹnit'o mọ̀ ohun gbogbo ti mbọ̀ wá ba on, jade lọ pade wọn, o sì wí fun wọn pe : Tali ẹnyin nwá? Nwọn sì da A l'ohùn wipe : Jesu ti Nasareti. Jesu sì wí fun wọn pe : Emi ni yi. Juda, ẹnit'o fi I hàn, sì duro pẹlu wọn. Bi Jesu sì ti wí fun wọn pe : Emi ni yi, nwọn pada sẹhin, nwọn sì ṣubu lulẹ. Nigbanà ni O sì tún bi wọn lère, wipe : Tani ẹnyin nwá ? Nwọn sì wipe : Jesu ti Nazareti. Jesu dahùn, Emi ti wí fun nyin pe : Emi ni yi. Nje bi Emi li ẹnyin ba nwá, ẹ jẹ ki awọn wọnyi ma ba ọna ti wọn lọ. Ki ọrọ nà ki o lè ṣẹ, eyiti o wipe : Ọkan ninu awọn ti Iwọ ti fun mi, Emi kó sọ ọ nù. Nigbanà Simoni Piteru, enit'o ni idà, o fà a yọ, o sì ṣà ọkan ti ise iranṣẹ olori alufa, o sì ke etí ọtún rẹ̀ sonù. Orukọ iranṣẹ nà a mà jẹ Malku. Ṣugbọn Jesu wí fun Piteru pe : Fi idà rẹ sinu àkọ rẹ̀. Kalisi ti Baba mi ti fi fun mi, Emi o ha ṣe alaimu u bi? Nigbanà li awọn ọmọ-ogun, ati olori ẹṣọ. ati awọn iranṣẹ awọn Ju, mu Jesu, nwọn sì de E ; Nwọn tètè mu U lọ sodọ Anna ;

nitori on ni iṣe ana Kaifa, ẹniti iṣe olori alufa l'ọdún nâ. Kaifa sà ni iṣe ẹnit'o ti ba awọn Ju gbimọ pe, o yẹ ki ọkọnri kan ba kú fun awọn enia. Simoni Piteru ati ọmọ-ẹhin kan miran sì ntọ Jesu lẹhin. Ọmọ ẹhin nâ sì jẹ ẹniti olori alufa mọ, o sì ba Jesu wọ afin olori alufa lọ. Ṣugbọn Piteru duro li ẹnu ọna lode. Nitorinâ ọmọ-ẹhin miran nâ, ẹniti olori alufa ti mọ, o jade lọ, o sọ fun ẹniti nṣọ ẹnu ọna, o sì mu Piteru wọle. Nigbanâ li ọmọ-ọdọ biri nâ ti nṣọ ẹnu wí fun Piteru pe : Ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin ọkọnri yi pẹlu kọ iwọ iṣe? O wí pe : Emi kì iṣe on. Awọn ọmọ-ọdọ ati awọn onṣẹ sì duro ti iná ẹyín, nwọn sì nyána, nitoriti o jẹ ìgba otutù. Piteru sì duro pẹlu wọn, o nyána. Nigbanâ li olori alufa bi Jesu lêre nipa ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ ati ti ẹkọ rẹ. Jesu da a lohùn wipe ; Emi nsọrọ nigbangba fun araiye ; nigba-gbogbo li emi nkọni ninu sinagogu, ati ni tempeli, nibiti awọn Ju imâ pejọ nigba-gbogbo ; emi kò sì sọ ohunkohun ni ìkọkọ. Eṣe ti iwọ ti mbi mi lère? Bi awọn ti o gbọ ọrọ mi lère, ohun ti mo wí fun wọn ; kiyesi i, nwọn mọ ohun ti mo wí. Bi o sì ti wí bẹ·tán, ọkan ninu awọn onṣẹ, ti o duro leti ọdọ rẹ sì fi atẹlẹ ọwọ rẹ gbá Jesu loju, wipe : Olori alufa ni iwọ nda lohùn bẹ? Jesu da a lohùn wipe : Bi o ba ṣepe ibi ni mo wí, jẹri sì ibi nâ, ṣugbọn bi o ba dara, èṣe ti iwọ fi nlù mi? Anna sì dè e, o sì rán a lọ sọdọ Kaifa olori alufa. Simoni Piteru sì duro, o nyána. Nigbanâ ni nwọn wí fun u pe : Ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ pẹlu kọ iwọ iṣe? O sẹ, o sì wipe. Emi kì iṣe on. Ọkan ninu awọn ọmọ-ọdọ olori

alufa, ẹniti işe ibatan, ẹniti Piteru ke etí rẹ̀ sọnù, wípe : Kì işe iwọ ni mo ri pẹlu rẹ̀ li ọgbà ? Piteru sì tún sẹ́, lojukannâ akukọ sì kọ. Nigbanâ ni nwọn mu Jesu lati ile Kaifa lọ si ile ẹjọ. O sì jẹ kutukutu owurọ̀ ; awọn tikalawọn kò wọ̀ inu ile ẹjọ, ki nwọn ki o má ṣe alaimọ́, şugbọn ki nwọn ki o lè jẹ ọdọ agutan Irekọja. Nigbanâ ni Pilatu jade tọ̀ wọn lọ, o sì wípe : Ẹsun kili ẹnyin ni si ọkọnri yi ? Nwọn sì dahùn wí fun u pe : Iba ṣe pe on kì işe arufin, awa kì ba ti fa A le lọwọ́. Nigbanâ ni Pilatu wí fun wọn pe : Ẹ mu U, ki ẹ ṣe idajọ rẹ̀ gẹgẹ bi ofin nyin. Awọn Ju da a lohùn wipe : Kò tọ̀ fun wa nipa ofin lati pa ẹnikẹni. Ki ọ̀rọ nâ ti Jesu ti sọ ki o lè ṣẹ, nigbati O nṣe apẹrẹ irú ikú ti on o kú. Nigbanâ ni Pilatu tún wọ̀ inu ile ẹjọ lọ, o sì pè Jesu , o sì wí fun U pe : Ngbọ́, ọba awọn Ju ni Iwọ işe ? Jesu da a l'ohùn pe : Iwọ wí nkan yi fun ara rẹ, tabi ẹlomiran sọ ọ fun ọ nitori mi ? Pilatu dahùn wipe : Emi işe Ju bi ? Awọn ará ilú rẹ tikalarẹ, ati awọn olori alufa li o fà Ọ le emi l'ọwọ́. Kini Iwọ ṣe ? Jesu dahùn wipe : Ijọba mi kì işe ti aiye yi ; ibaṣepe ijọba mi işe ti aiye yi, dajudaju awọn ọmọ-ọdọ mi iba jà, ki a má ṣe fi mi le awọn Ju l'ọwọ́. Şugbọn ijọba mi kì işe lati ihinyi lọ. Nitori nâ ni Pilatu wí fun U pe : Nje Iwọ ha ṣe ọba bi ? Jesu dahùn wipe : Iwọ wipe : Ọba li emi işe ; nitori eyi li a ṣe bí mi, ati nitori idi eyi ni mo sì ṣe wá si aiye, ki emi ki o lè jẹri si otitọ. Enikẹni ti o ba ṣe ti otitọ, ngbọ́ ohùn mi. Pilatu wí fun U pe : Kili otitọ? Nigbat'o sì ti wí eyi tán, o tún jade tọ̀ awọn Ju lọ, o sì wí fun wọn pe: Emi kò ri ẹbi kan

l'owó rè rara. Ṣugbọn ẹnyin ni iṣe kan pe, ki emi ki o mà da ọkan silẹ fun nyin nigba ọdún irekọja. Nitorinâ ẹnyin nfẹ ki emi o da Ọba awọn Ju silẹ fun nyin. Nigbanâ ni gbogbowọn sì túnkigbe soke wipe : Kì iṣe ọkọnri yi, bikoṣe Baraba. Olè sá ni Baraba iṣe. Nigbanâ ni Pilatu mu Jesu, o sì nà a. Awọn ọmọ-ogun sì wùn adé ẹgún, nwọn sì fi de e lori, nwọn sì fi aṣọ igunwà ododo wọ ọ. Nwọn tọ ọ wá, nwọn sì wipe : Alafia, Ọba awọn Ju ? Lojukannâ nwọn sì fi ọwọ́ wọn gbá a loju. Lẹhin eyi, Pilatu túnjade, o sì wí fun awọn Ju pe : Kiyesi i, mo mu u jade tọ nyin wá, ki ẹnyin ki o lè mọ pe, emi kò ri ẹbi kan lọwọ́ rẹ̀ Nigbanâ ni Jesu jade wá, ti on ti adé ẹgún ati aṣọ igunwà ododo, Pilatu sì wí fun wọn pe : Ẹ wò ọkọnri na ! Nigbati awọn olori alufa ati awọn onṣẹ wọn ri i, nwọn kigbe soke wí pe : Kàn a mọ́ agbelebu, kàn a mọ́ agbelebu. Pilatu wí fun wọn pe : Ẹ mu u, ki ẹ sì kàn a mọ́ agbelebu, nitoriti emi kò ri ẹbi kan lọwọ́ rẹ̀. Awọn Ju da a lohùn wí pe : Awa li ofin kan, ati nipa ofin nà o ye lati kú, nitoriti o fi ara rẹ̀ ṣe Ọmọ Ọlọrun. Nigbati Pilatu gbọ́ ọ̀rọ̀ni, o bẹ̀ru gidigidi, o sì túnwọ inu ile ẹjọ́ lọ, o sì wí fun Jesu pe : Nibo ni iwọ ti wá ? Ṣugbọn Jesu kò da a lohùn. Nigbanâ ni Pilatu wí fun u pe : Iwọ kò mọ́ pe, emi li agbara lati kàn ọ mọ́ agbelebu, emi sì lagbara lati da ọ silẹ? Jesu dahùn wipe : Iwọ kì ba ti lagbara kan lori mi, bikoṣe pe a ti fi i fun ọ lati òke wá, nitorinâ ẹnit'o fà mi le ọ l'owọ́ l'o ni ẹṣẹ pọ̀ju. Lati igbanâ lọ ni Pilatu sì ti nwá ọ̀na lati da a silẹ. Ṣugbọn awọn Ju kigbe soke wipe : Bi

iwọ ba da ọkọnrí yi silẹ, iwọ kì iṣe ọrẹ Sesari. Nigbati Pilatu ti gbọ́ irú ọrọ ni, o mu Jesu jade wá, o sì joko lori itẹ́ idajọ, nibi kan t'a npè ni Litostrotos li ède Griki, ati Gabbata li ède Heberu. O sì jẹ ọjọ́ ipalẹmọ́ ọdún Irokoja, nigba wakati ẹkẹfa, Pilatu sì wí fun awọn Ju pe : Ẹ wò ọba nyin ! Sugbọn nwọn kigbe soke wipe : Mu U kuro, mu Ù kuro, kàn A mọ́ agbelebu. Pilatu wí fun wọn pe : Emi o ha kàn ọba nyin mọ́ agbelebu bi ? Awọn olori alufa dahún wipe : Awa kò li ọba kan bikoṣe Sesari. Nigbanà li o fà a le wọn lọwọ́ lati kàn A mọ́ agbelebu. Nwọn sì mu Jesu, nwọn sì fà a jade lọ. On sì nrù agbelebu rẹ̀ lọ si ibikan t'a npè ni Kalfari, ati Golgota li ède Heberu, nibiti nwọn gbé kàn a mọ́ agbelebu, ati awọn meji miran pẹlu rẹ̀, ekini li apa kan, ati ekeji li apa keji, Jesu sì wà lârin. Pilatu sì kọwe akọle kan, o ti le ori agbelebu nâ. Ohun t'a sì kọ́ ni : Jesu ti Nisareti ọba awọn Ju. Ọpọlọpọ awọn Ju l'o kà iwe akọle yi, nitori ibi t'a gbé kàn Jesu mọ́ agbelebu sunmọ́ etí ilú. A sì kọ́ ọ l'ède Heberu, ati ni ti Griki, ati ni ti Latini. Nigbanà ni awọn olori alufa wí fun Pilatu pe : Mà ṣe kọ́ ọ pe, Ọba awọn Ju, ṣugbọn pe On l'o wipe : Emi li ọba awọn Ju. Pilatu da wọn l'ohùn wipe : Ohun ti mo ti kọ́ tán, mo ti kọ́ tán. Nigbati awọn ọmọ-ogun kàn Jesu mọ́ agbelebu tán, nwọn mu aṣọ rẹ̀, nwọn sì pín wọn sì ipa mẹrin, apakan fun ọmọ-ogun kọkan, ati ẹwu rẹ̀ pẹlu. Ewu nâ kò li ojuran, nwọn wún u lati òke titi jalẹ ; nitorinâ nwọn wí fun ara wọn pe : Jẹ ki awa máṣe fà a ya, ṣugbọn kì a ṣẹ gegé nitori rẹ̀, ti eniti yio jẹ, ki ọrọ nâ ti

Iwe mimọ́ ki o lè ṣẹ, ti o wipe : Nwọn pín aṣọ mi fun ara wọn, nwọn sì ṣẹ gegé fun aṣọ ilekè mi. Nkan wọnyi li awọn ọmọ-ogun ṣe. Lẹba agbelebu Jesu ni iyá rẹ̀, ati arabirin iyá rẹ̀, Maria, aya Kleofa ati Maria Magdalene duro. Nitorinâ nigbati Jesu ri iyá rẹ̀, ati lẹba rẹ̀ ọmọ-ẹhin nâ ti On fẹ́, O wí fun iyá rẹ̀ pe : Obirin, wò ọmọ rẹ. Lẹhinnâ O wí fun ọmọ-ẹhin nâ pe : Wò iyá rẹ. Lati wakati nâ lọ li ọmọ-ẹhin nâ sì ti mu u lọ sì ile ara rẹ̀. Lẹhin eyi, bi Jesu ti mọ̀ pe a ti pari ohun gbogbo tan, ki ọ̀rọ Iwe mimọ́ ki o lè ṣẹ, o wipe : Orungbẹ ngbẹ mi. Bi ohun èlo kan ti o kún fun oti kikan sì ti wà nibẹ̀, nwọn tẹ̀ spunge (ohun iwẹ̀ju) bọ inu rẹ̀, nwọn fi i le ori ọpá hisopu, nwọn sì fi i si i li ẹnu. Nigbati Jesu sì ti gbà oti kikan nâ, o wipe : O pari. O sì tẹ ori rẹ̀ ba, o jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ́ (*A kunlẹ nibi*). Ki okú nâ ki o máṣe wà lori agbelebu li ọjọ́ isimi, nitoriti iṣe ọjọ́ ipalẹmọ, ati pe ọjọ́ ọdún nla ni ọjọ́ isimi ti o tẹle, awọn Ju bẹ̀ Pilatu pe, ki a lè ṣẹ́ egungun itan wọn, ati ki a lè gbé wọn kuro nibẹ̀. Nigbanâ ni awọn ọmọ-ogun de, nwọn sì ṣẹ́ egungun itan ti ekini, ati ti ekeji, ti a kàn mọ́ agbelebu pẹlu rẹ̀. Sugbọn nigbati nwọn de ọdọ Jesu, ti nwọn sì ri pe O ti kú tán, nwọn kò ṣẹ́ egungun itan rẹ̀, sugbọn ọkan ninu awọn ọmọ-ogun nâ fi ọ̀kọ gún Ú l'ẹgbẹ, lojukannâ ẹ̀jẹ ati omi sì tú jade. Enit'o ri sì jẹri, otitọ sì li ẹri rẹ̀, o sì mọ̀ pe ôtọ li on wí, ki ẹnyin sì lè gbà a gbọ́ pẹlu. Nitori a ṣe nkan wọnyi, ki ọ̀rọ nâ ti Iwe mimọ́ ki o lè ṣẹ, ti o wipe : A kì yio ṣẹ́ egungun rẹ̀. Iwe mimọ́ sì tún wí li apa miran pe : Nwọn o mawò ẹnití a gún li ọ̀kọ

Lẹhin nkan wọnyi ni Josefu ará Arimatea (ẹniti iṣe ọmọ-ẹhin Jesu, ṣugbọn ni ikokò nitori ibẹ̀ru awọn Ju), o bẹ̀ Pilatu ki on ki o lè gbé okú Jesu kuro. Pilatu sì fun u l'aṣẹ. Nitorinâ li o wá, o sì gbé okú Jesu kuro. Nikodemu pẹlu sì wá, ẹniti'o tọ̀ Jesu wá l'oru nişiwaju, o sì mu idapọ ojia ati aloe wá, o to ìwọn ọgọrun li oşuwọn. Nigbanâ ni nwọn gbé okú Jesu, nwọn sì fi aṣọ ọgbọ di I pẹlu turari, gẹgẹ bi iṣe awọn Ju ti ri ni isinkú wọn. Ọgba kan sì wà nibiti a gbé kàn Jesu mọ agbelebu, ibojì titun kan sì wà ninu ọgba nâ, ninu eyiti'a kò ti itẹ́ ẹnikẹni sì ri. Ninu rẹ̀ ni nwọn sì tẹ́ Jesu si, nitori ọjọ́ ipalẹmọ awọn Ju; nitori ibojì nâ sunmọ tosi.

Lẹhin eyi saserdoti kà adura t'o tẹle eyi.

Ẹnyin olufẹ mi, ẹ jẹ k'a gbadura fun Ijọ awọn enia mimọ́ Ọlọrun, ki Ọlọrun Oluwa wa ki o fiyesi lati fun u l'alafia nibi gbogbo, lati fun u li iṣọkan ati lati dàbobo o; ki o sì mu ki awọn ijọba ati awọn ọba tẹriba fun ofin rẹ̀, ki o sì fun gbogbo wa li irọrun ati idakẹjẹ́ li ọjọ́ aiye wa, ki awa lè ma yìn Ọlọrun Olodumare l'ogo.

Saserdoti wípe : Ẹ jẹ k'a gbadua.

Ọtún ti saserdoti wipe : Ẹ jẹ ki a kunlẹ.

Osìn ti saserdoti wipe : Ẹ dide.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o fi ogo rẹ̀ hàn gbogbo awọn orilẹ-ède nipasẹ

Kristi, pa iṣẹ ânu rẹ mọ́, ki Eklesia rẹ ti o tàn kalẹ nibigbogbo ki o lè fi iduro ṣinṣin igbagbọ́ tẹramọ́ ni jijẹwọ́ orukọ rẹ. nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Ẹ jẹ k'a gbadura fun Papa wa mimọ́ julọ, ki Ọlọrun Oluwa wa, ti o fi i joyè Biṣopu, ki o pa a mọ́ li alafia ati li ilera, ki o lè ṣakoso Ijọ awọn enia mimọ́ Ọlọrun.

Ẹ jẹ ki agbadua.—Ẹ jẹ ki a kunlẹ.—Ẹ dide.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, idajọ ẹniti nkan gbogbo fidikalẹ, fi ânu kiyesi adura wa, nipa iyọ́nu rẹ ki o si pa Oluṣọ́ wa ayanfẹ mọ́ fun wa, ki awọn kristiani ti o wà labẹ ijọba Papa titobi nâ, eyiti Iwọ tikararẹ dá silẹ, ki o lè mâ posi i li igbagbọ́; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ẹ jẹ ki awa gbadua fun gbogbo awọn Biṣopu, awọn Saserdoti, awọn Diakoni (ọtún ti saserdoti), awọn Subdiakoni (òsìn ti saserdoti), awọn Akoliti (olusìn saserdoti), awọn Alésujade, awọn Akàwé mimọ́, awọn Oluṣọ́ ẹnu ọ̀na ile Ọlọrun, awọn onijẹwọ́ igbagbọ́, awọn wundia, awọn opó ati fun gbogbo agbajọ enia Ọlọrun. Ẹ jẹ ki a gbadua.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, nipa Ẹmí ẹniti a nsọ gbogbo agbajọ Eklesia di mimọ́,

t'a sì nṣe akoso rẹ̀, gbà ẹ̀bẹ ti awa nran s'iwaju rẹ fun gbogbo awọn oninuru oloyè mimọ́ ninu rẹ̀, nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ ki gbogbo nwọn lè mâ sìn Ọ nitôtọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ẹ jẹ k'a gbadura fun awọn onigbagbọ́ titún wa ti o nfẹ́ gbà ibatisi, ki Olọrun Oluwa wa ki o ṣí etí ọkàn wọn ati iṣura ânu rẹ̀ silẹ pe, nipa iwẹ̀nu atunbí, lẹhin igbati nwọn ti ri idarijì gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wọn gbà, ki a lè gbà wọn pẹlu sinu ìye awọn ọmọ Jesu-Kristi Oluwa wa.

Adura.

Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o mâ nu Ijọ awọn enia rẹ bísi i nigbagbogbo nipa ọmọ titún, sọ igbagbọ́ ati imọ̀ awọn onigbagbọ́ titun wa di pupọ̀ k'a lè fi omi ibatisi tún wọn bí, ki a sì lè da wọn pọ̀ mọ́ awọn ọmọ rẹ nipa isọdọmọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Enyin Olufẹ mi, ẹ jẹ k'a bẹ̀bẹ lọdọ Olọrun Bada Olodumare, ki o wẹ̀ gbogbo araiye nù kuro ninu gbogbo iṣina ati ẹkọkẹkọ; ki o lé ajakalẹ arùn kuro; ki o sì mu iyàn kuro l'ọdọ wa, ki o ṣí tubu silẹ, ki o sì ṣẹ ẹ̀wọn; ki o fun awọn arina li âbọ̀ rere, ati awọn alarùn ni ilera, ki o sì mu awọn ti nrìn l'oju omi de ebute igbalà. Ẹ jẹ k'a gbadura. etc.

Adura

Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti iṣe

itunu awọn olupọnju ati agbara awọn alailera, jẹ ki adura awọn ti nkigbe pè Ọ ninu ipọnju-kiponju lè dé ọdọ rẹ, ki gbogbo wọn ninu aini wọn lè mâ yọ nipa iranlọwọ ânu rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ẹ jẹ ki a gbadua fun awọn Aladamọ ati fun awọn oniyapa kuro ninu isọkan Eklesia, ki Olọrun Oluwa wa ki o gbà wọn kuro ninu gbogbo isìna ati ẹkọ́kẹkọ́, ki o sì fiyesi i lati mu wọn pada wá sọdọ Iyá mimọ́, Eklesia katolika atí apostolika.

Ẹ jẹ ki a gbadua—Ẹ jẹ ki a kunlẹ—Ẹ dide.

Adura.

Olọrun Olodumare ati aiyeraiye. Iwọ ti o fẹ́ igbalà gbogbo awọn enia, ti kò sì fẹ́ ki ẹnikan ṣegbé, fi ojurere wò awọn enia ti a tipa arekereke èṣu tàn jẹ́, ki gbogbo awọn aṣìna ki o lè kọ́ gbogbo ẹkọ́ eke silẹ, ki nwọn sì lè pada wá sinu isọkan otitọ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ẹ jẹ ki a gbadua pẹlu fun awọn Ju alaisôtọ, ki Olọrun Oluwa wa mu iboju ti mbẹ li aiya wọn kuro, ki nwọn pẹ'lu sì lè mọ Jesu-Kristi Oluwa wa.

Adura.

Olọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti kò ṣa awọn enia Ju alaisôtọ tì kuro ninu ânu rẹ, fi ojurere gbọ́ adura ti awa nrán siwaju rẹ fun awọn enia ọlọkàn lile nà, ki nwọn ki o lè mọ

Jesu-Kristi, ẹniti iṣe imọlẹ otitọ, ki a si lè yọ wọn kuro ninu òkunkun wọn ; nipasẹ Jesu-Kristi wa Oluwa. Amin.

Ẹ je gb'adura fun awọn keferi pẹlu, ki Ọlọrun Ọlodumare ki o gbà ọkàn wọn kuro ninu ìwa buburu, ki nwọn ki o lè kọ orisa wọn silẹ, ki nwọn ki o si lè yipada si Ọlọrun otitọ ati alàye, ati si Ọmọ bibi rẹ nikanṣoṣo, Jesu-Kristi Ọlọrun ati Oluwa wa.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti kò fẹ ikú ẹlẹṣẹ, bikoṣe pe ki o yè, ti ojurere gbọ adura wa, ki Iwọ ki o gbà awọn keferi kuro ninu iborisa, ki o si gbà wọn sinu Ijọ awọn enia rẹ, nitori ogo ati ọlá orukọ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IBỌLAFUN AGBELEBU

Saserdoti kọrin eyi : Wò igi agbelebu, lori eyiti a ti igbalà araiye kọ.

Chorus. Ẹ wá, ki a foribalẹ fun U.

Nigbati a mbọlá fun agbelebu, a kọrin eyi :

Ẹnyin enia mi, kini mo ṣe si nyin ? Ninu kini mo ba nyin ninu jẹ ? Ẹ da mi lohùn ; nitoriti emi mu nyin jade ni ilẹ Egipti, ni ẹnyin ṣe pèse agbelebu silẹ fun Olugbala nyin.

Ọlọrun mimọ, Ọlọrun mimọ ati alagbara, Ọlọrun mimọ ati alaikú, ṣãnu fun wa.

Ahọn mi, fi ayọ̀ kọrin ìja t'o l'ogo ni, k'o sì fi inu didùn yìn ìṣẹgun olokiki ti Oluwa araiye ti ṣe, nigbat'a ru U l'ẹbọ lori agbelebu

Ọlọrun ti ṣànu fun enia, ti a tipa arekereke èṣu tanjẹ, t'o sì ri ikú gbà nipa jijẹ eso igi; O sì ti pinnu rẹ̀ lati fi igi ṣe atunṣe òfo ti a ṣe nipa igi.

Njẹ Ọlọrun fẹ́ lati túnu gbà wa là, o sì jẹ ki arekere mimọ́ bori òpọ arekereke olùdanwò, ki ohun nà lè mu igbalà wá fun wa, ti ọtá wa fi pa wa lara.

Nigbati akokò mimọ́ pe, a rán Ọmọ Baba aiyeraiye ati Ẹlẹda aiye jade lati ọrun wá, ẹniti o mu ẹran ara wọ̀, ti a sì bí ninu Wundia.

O sọkun, o sì dubulẹ bi ọmọ-ọwọ ninu ibujẹran, O sì jẹ ki iyá rẹ̀ Wundia fi ọjá wé e, ki o sì fi dè e li ọwọ́ ati li ẹsẹ̀.

Nigbati o jù ọgbọ̀n ọdún lọ ti a dá fun ara ikú rẹ̀, O fi ara rẹ̀ fun ijiyà nitori wa tifẹtifẹ, a sì gbé e kọ́ sori agbelebu, nibiti a gbé ru u ẹbọ nitori wa.

Wò bi a ti so o rọ̀ sori igi agbelebu, bi a sì ti fun u li oti kikan mu li orungbẹ rẹ̀. A sì gún u li ẹgún, iṣó ati ọkọ lara; omi ati ẹjẹ sì tú jade lati inu ọgbẹ́ rẹ̀ wá. Eyiyi ni ibaluwẹ ninu eyiti o tọ́ ki a wẹ̀ ẹṣẹ gbogbo awọn enia nù.

Igi giga, tẹ ẹká rẹ silẹ, ki o sì di lilẹ, jẹ ki igi rẹ lile ki o dì rirọ, má sì ṣe nà ara Ọba ọrun tàntan, ki o mába jiyà pupọju.

Iwọ nikan li o yẹ lati gbé ọdọ agutan ẹbọ ti araiye ati lati mu araiye ti nṣegbé lọ de ebute bi ọkọ̀ Noa miran, awọn tí a fi ẹjẹ ti o tú jade lati inu ọdọ-agutan nà wá wọn.

Ogo titilai ni fun Ọlọrun Ẹni-Mẹtalọkan mimọ ; ọlá ọkannà ni fun Baba, Ọmọ ati Ẹmi-Mimọ, ki a sì mâ yìn oruko Ọlọrun kan ninu ẹni mẹta logo titi aiye ti kò nipẹkun. Amin.

ORIN VEXILHA REGIS

1 Wò ọpagun Ọba ogo ;
Elẹda Ọlọrun wa,
T'a kàn mọ igi itiju
L'agbelebu fi hàn wa.

2 Lat'inu ihà rẹ mimọ
T'a fi ọkọ t'o mú gún
L'ẹjẹ on omi ṣan jade,
Ti o wẹ ẹṣẹ wa nù.

3 Nigbanà l'ọrọ ti Dafidi
Ti so tele ṣẹ, wipe :
Lat'ori igi l'Ọlọrun
Jọba l'ori enia.

4 Igi ọwọn t'o tàn molẹ,
T'ẹjẹ Jesu ṣe l'ọṣọ.
'Wọ ye k'a yan ọ farakan.
Ẹya ara rẹ mimọ.

5 Bi Iwọ ti l'alafia to
Igi ọwọn t'o logo !
Owo idasilẹ aiye
L'Iwọ gbé si apa rẹ.

6 Iwọ ni iwọn t'a fi wọn
Ara Olugbala wa,
Iwuwo eyit'o tẹwọn
Ikogun ọrun-apâdi.

7 A kí Ọ, igi ayọ̀ wa!
Lì akokò mimọ́ yi
M'ododo pọ̀ si l'ọkàn wa,
K'o sì f'ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wa.

8 Ki gbogbo ẹmi k'o yìn Ọ,
Olọrun mẹtalọkan,
K'Ó jọba lailai l'ori wa,
T'Iwọ f'agbelebu gbalà.

SATURDAY MIMỌ

Iṣẹ isìn ode t'a tetekọṣe ni ibukún inú titún, lẹhin igbati a ti pa gbogbo iná ni ile Olọrun, lati fi ṣapẹrẹ pe nipa ikú Jesu-Kristi a ti pa Majẹmu atijọ rẹ̀, ati pe nipa ajinde rẹ̀ kuro ninu okú, a ti fi imọlẹ ofin titún fun araiye. Lẹhin eyi, saserdoti bukún fun wòro turari marun, lati fi ṣapẹrẹ turari t'a fi kún okú ti Jesu-Kristi, ati ọgbẹ́ marun ti Olugbala wa fé fi pamọ́ l'ara rẹ̀ t'o logo. Lẹhinnâ a bunkúnfun fitila eleka mẹta, t'a tàn nigba mẹta l'ogo Olọrun mẹta l'ọkan mimọ́; nipa eyi a ran awọn enia leti lati dupẹ lodọ Jesu-Kristi, ẹniti iṣe imọlẹ otitọ, nitoriti Ó fi òrọ ijinlẹ ti Olọrun mẹtalọkan mimọ́ hàn wa. Nigbanâ li a fi orin ayọ̀ nla bunún fun Vela Paska, t'o jasi awọ-sanma iná t'o fi imọlẹ fun awọn ará Israeli li aginjù li oru; o sì tún jasi Jesu-Kristi, ẹniti iṣe imọlẹ tótọ awọn enia, ti o sì fi idánṣanṣan ẹkọ́ rẹ̀ ṣe imọlẹ si aiye.

MISA

Adura

Ọlọrun, Iwọ ti o ṣe imọlẹ si oru mimọ yi nipa ajinde ologo ti Jesu-Kristi Oluwa wa, pa ẹmí isọdọmọ mọ ninu awọn ọmọ titún ti Ijọ awọn enia rẹ, ki awọn ti a tún dá li ọkàn ati li ara lè fi ọkàn mimọ sìn Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Kol. 3).

Ará mi, bi ẹnyin ba ti jinde pẹlu Kristi, ẹ mâ ṣafẹri ohun ti mbẹ loke, nibiti Kristi gbé joko li ọwọ ọtún Ọlọrun. Ẹ mâ nagasi ohun ti mbẹ li ọrun, kì iṣe si ohun ti mbẹ li aiye; nitori ẹnyin ti kú, a si fi iye nyin pamọ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun. Nigbati Kristi, ti iṣe iye nyin, yio fara rẹ hàn, nigbanâ li ẹnyin yio farahàn pẹlu li ogo.

Graduali. Alleluia, alleluia, alleluia (ẹ mâ fi ayọ yìn Ọlọrun). Ẹ mâ yìn Oluwa, nitoriti o ṣeun, nitoriti ânu rẹ duro lailai. Ẹ mâ yìn Oluwa. ẹnyin gbogbo keferi; ẹ jumọ yìn I, ẹnyin gbogbo orilẹ-ède, nitoriti ânu rẹ duro ṣinṣin lori wa, otitọ Oluwa si duro lailai.

Ihin-rere (Mat. 28).

Li opin ọjọ isimi, nigbati ilẹ ọjọ kini ọsẹ ti bẹrẹ si mọ, Maria Magdalene, ati Maria keji wá lati wò iboji. Si wò o, ìsẹlẹ nla sẹ; nitoriti Angẹli Oluwa ti ọrun sọkalẹ wá, o si yí okuta kuro l'ẹnu ọna, o si joko le. Oju rẹ dabi manamana, aṣọ rẹ si fun bi snô. Nitori ẹ̀ru rẹ

awọn oluṣọ́ sì nwariri, nwọn dabi okú. Ṣugbọn Angẹli nâ dahùn, o sì wí fun awọn obirin nâ wipe : Ẹ má bẹ̀ru, nitori emi mọ̀ pe ẹnyin nwá Jesu, t'a ti kàn mọ́ agbelebu. Kò si nihinyi ; nitori ti O jinde gẹgẹ b'o ti wí. Ẹ wá wò ibiti Oluwa dubulẹ ; k'ẹ sì yara lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe, O jinde kuro ninu okú ; sì wò o, O ṣaju nyin lọ si Galili, nibẹ̀ li ẹnyin o gbé ri I. Wò o, mo sọ ọ fun nyin tẹlẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ l'ọdọ rẹ̀, gbà adura awọn enia rẹ ti on ti ọrẹ hostia yi, ki ọ̀rọ ijinlẹ ti Paska t'awa bẹ̀rẹ si ṣe ọdún rẹ̀ lè kún wa lọwọ́, nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ ; lati ri ìye ti kò nipẹkun gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Vesperi

Alleluia, alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹ mâ yìn Oluwa ẹnyin gbogbo orilẹ-ede, ẹ yìn I, enia gbogbo ; nitoriti ânu rẹ̀ duro ṣinṣin l'ori wa, otitọ Oluwa sì duro lailai. Ogo ni fun Baba, etc.

Antifona. Li opin ọjọ́ isimi, nigbati ilẹ ọjọ kini ọsẹ ti bẹ̀rẹ si mọ́. Maria Magdalene ati Maria keji wá lati wò ibojì. Alleluia.

Orin Magnifikat, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ̀, da ẹmi ifẹ̀n rẹ sori wa, ki gbogbo awọn ti iwọ fi sakramenti kannâ ti Paska bọ́, lè ni ọkàn ati ifẹ́ kannâ si ara wọn ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN NLA TI PASKA

Tabi Ijọ́ Ajinde Jesu-Kristi kuro ninu okú.

Ipilęṣẹ ti Misa. Mo jinde, Oluwa. emi sì wà lodọ rẹ sibẹ̀, alleluia, iwọ sì ti fi ọwọ́ rẹ lé mi, alleluia, ọgbọ́n rẹ sì ti ṣe ohun iyanu fun mi. Alleluia, alleluia, alleluia. *Ps.* Oluwa. iwọ ti wadi mi, iwọ sì ti mọ̀ mi; iwọ mọ̀ ikú mi ati ajinde mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o tipa iṣẹgun Ọmọ bibi rẹ nikanṣoṣo lori ikú ṣilẹkun iye ti kò nipẹkun silẹ fun wa; nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ, tifuni. ki awa lè mu ifẹ́ rere ti iwọ fi sinu wa nipa ṣiṣaju wa pẹlu ôre-ọfẹ rẹ wá si opin rere; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Epistoli (1 Kor. 5).

Ẹnyin ará mi, ẹ mu iwukara atijọ kuro ninu nyin, ki ẹnyin ki o lè jẹ iyẹfun titun, bi ẹnyin ti jẹ aiwukara, nitoriti a ti rù Kristi ti iṣe pẹlu ọdọ-agutan Paska wa lẹbọ nitori wa. Nitorinâ ẹ jẹ ki a ṣe ọdún nâ. kì iṣe pẹlu iwukara arankân ati ìwa buburu, bikoṣe pẹlu aiwukara inu funfun ati otitọ.

Graduali. Eyi li ọjọ́ ti Oluwa da, ẹ jẹ ki a mâ yọ̀, ki inu wa ki o sì ma dùn ninu rẹ. Ẹ fi iyìn fun Oluwa, nitori ti O ṣeun, nitoriti ânu

rẹ̀ duro lailai. Alleluia, alleluia. Jesu-Kristi ti iṣe ọdọ-agutan Paska wa li a rù lẹbọ.

ORIN VICTIMÆ PASKALI

Oluwa Jesu-Kristi ti iṣe ọdọ-agutan Paska wọn ni ki awọn kristiani ki o rù ẹbọ iyin si.

Ọdọ-agutan nà l'o rà awọn agutan pada, Jesu-Kristi ti iṣe alailẹṣẹ ti ba awọn ẹlẹṣẹ làja pẹlu Baba rẹ̀.

Ikú ati iye ti ha ara wọn jà gidigidi, ṣugbọn Olufunni li iye l'o ṣegun l'ori ikú nipa kikú, o si jọba làye.

Ngbọ́, Maria, ṣọ fun wa kini iwọ ri l'ọ̀na? Mo ri ibojì Kristi alâye ti on ti ogo ajinde rẹ̀. Mo ri Angẹli t'o jẹri rẹ̀, ti awọn ti aṣọ ogbọ ati aṣọ isinkú rẹ̀.

Jesu, ireti mi, ti jinde kuro ninu okú, on yio ṣaju awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ lọ si Galili.

A mọ̀ pe Jesu-Kristi jinde nitôtọ. Ọba, aṣẹgun ikú, ṣànu fun wa. Amin. Alleluia.

Ihin rere (Mark 16).

Nigbanâ ni Maria Magdalene ati Maria iyá Jakọbu, ati Salomi rà turari lati wá fi kùnra Jesu. Ni kutukutu awurọ̀ ojọ́ kini ọsẹ nwọn wá sibi ibojì nigbati ọrun bẹ̀rẹ si là. Nwọn sì ba ara wọn sọ̀rọ pe: Tani yio yí okuta kuro lẹnu ibojì fun wa? Nigbati nwọn sì wò o, nwọn ri pe a ti yí okuta nâ kuro, nitoripe o tobi gidigidi. Bi nwọn sì ti wọ̀ inu ibojì, nwọn ri ọmọkọnri kan joko li npa ọtún, ti o wọ̀ agbáda funfun, ẹ̀ru sì ba wọn. Sugbọn o

wí fun wọn pe : Ẹ má bẹ̀ru, ẹnyin nwá Jesu ti Nasareti, ti a kàn mọ́ agbelebu, o jinde, kò sì nihinyi, ẹ wò ibi ti nwọn gbé tẹ́ e si. Ẹ lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ ati Piteru pe o ṣaju nyìn lọ si Galili, nibẹ̀ li ẹnyin o gbé ri i bi o ti wí fun nyin.

Ifitọrẹ. Ilẹ aiye wariri o sì dakẹ jẹ nigbati Oluwa dide lati ṣe idajọ. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, gbà adura awọn enia rẹ ti on ti ẹbọ hostia yi ki ọ̀rọ-ijinlẹ ti Paska ti awa bẹ̀rẹsi ṣe ọdún rẹ̀ lè kún wa lọwọ́, nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ, lati ri ìyè ti kò nipẹ̀kun gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Jesu-Kristi ti iṣe ọdọ-agutan Paska wa li a ru lẹbọ. Alleluia. Nitorinâ ẹ jẹ k'a ṣe ọdún nâ pẹlu aiwukara inu funfun ati otitọ. Alleluia, alleluia, alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, dà ẹmí ifẹni rẹ sori wa, ki gbogbo awọn ti Iwọ fi sakramenti kannâ ti Paska bọ́, lè ni ọkàn ati ifẹ́ si kannâ si ara wọn; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Orin O filii et filiæ.

Ẹnyin kristiani, ẹ yọ̀;
Ọba ọrun, ọba ogo
Jinde n'isà okú loni. Alleluia.

Maria on Salome wá
Lati ba fi turari kùn
Ara Jesu Oluwa wa. Alleluia.

Awọn ọmọ-ẹhin meji,
Ti Magdalene ba sọ̀rọ,
Sare lọ sibi ibojì. Alleluia

Ṣugbọn Johan'apostoli
Ṣare yá Piteru koja,
O sì tete kọ de'boji. Alleluia.

Angẹli alaṣọ funfun
Joko le'boji, o sì wí
F'obiri pe : Jesu jinde. Alleluia.

Aw'ọmọ-ẹhin pejọpọ̀
Ni yara kan, Jesu sì wá
Wipe : Alafia fun nyin. Alleluia.

Nigbat'apostoli Toma
Gbọ́ pe Jesu Kristi jinde,
On kò fẹ́ lati gbà a gbọ́. Alleluia.

Jesu wí fun Toma pe :
Wò ihà, t'ọwọ́ t'ẹsẹ̀ mi.
Ma sì ṣe alaigbagbọ́ mọ́. Alleluia.

Nigbat'apostoli Toma
Ri gbogbo ogbẹ ti Kristi,
O wipe'Wọ l'Ọlọrun mi. Alleluia.

Alabukún fun li ẹni
Ti kò ri, ṣugbọn t'o gbagbọ́ ;
Nwọn yio jogun ọrun rere. Alleluia.

Jẹ k'a yọ̀ l'ojọ́ mimọ́ yi,
K'a sì yìn Ọlọrun logo
K'a sì f'ogo at'ọlá fun U. Alleluia.

Jẹ k'a ṣọpẹ gidigidi
Fun Jesu t'o ra wa pada
T'o sì ṣikun ọrun fun wa. Alleluia,

MONDAY NI ỌDUN PASKA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa mu nyin wá sinu ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin, alleluia, ki ofin Oluwa ki o wà li enu nyin nigbagbogbo. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹ fi iyìn fun Oluwa, ki ẹ sì pè orukọ rẹ̀ ; ẹ rohin iṣẹ rẹ̀ lârin awọn keferi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o tipa ọdún Paska fun araiye li ọna atidé ibi alafia, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, dà ọpọ ôre-ọfẹ rẹ sori awọn enia rẹ, ki nwọn ki o lè ri idandè pipé ti ọkàn kuro ninu èṣẹ gbà lọdọ rẹ, bẹ̀ni ki nwọn ki o sì lè de ibi iye ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iṣe apost. 10).

Ni ijọ́ wọnyi ni Piteru dide duro lârin ijọ awọn enia, o wipe : Ẹnyin ọkọnri ati arà,

ẹnyin mọ ohun ti o ṣẹ ni gbogbo Judea, ti o bẹrẹsi lati Galili wá, lẹhin Ibatisi ti Johanu wàsu, bi Ọlọrun ti dà Emí-Mimọ ati ọlá si Jesu ti Nasareti lori, ẹniti o nkiri nibigbogbo lati ṣe ôre ati lati ṣe dida ara gbogbo awọn ti o wà labẹ ọlá èṣu, nitoriti Ọlọrun wà pẹlu rẹ̀. Awa sì jẹ ẹlẹri gbogbo ohun ti O ṣe ni ilẹ awọn Ju ati ni Jerusalemu; ẹniti nwọn pa, ti nwọn sì fi há lori igi. On li Ọlọrun jinde ni ijọ́ kẹta, o sì fi i hàn nigbangba; kì ise fun gbogbo enia, bikoṣe fun awọn ẹlẹri ti a yàn tẹlẹ lati ọdọ Ọlọrun wá, fun awọn ti o bá a jẹ, ti o sì ba a mu, lẹhin igbati O jinde kuro ninu okú. O sì paṣẹ fun wa lati wàsu fun awọn, ati jẹri pe on l'a yàn lati ọdọ Ọlọrun ṣe Onidajọ âye on okú. On ni gbogbo awọn woli jẹri fun pe, ẹnikẹni t'o gbà a gbọ́, yio ri imukuro ẹ̀ṣẹ gbà nipasẹ orukọ rẹ̀,

Graduali. Eyi li ọjọ́ ti Oluwa da, ẹ jẹ ki a mâ yọ̀, ki inu wa ki o sì mâ dùn ninu rẹ̀. Jẹ ki Israeli wí nisisiyi pe Oluwa ṣeun, ati pe ânu rẹ̀ sì duro lailai. Alleluia, alleluia. Angẹli Oluwa ti ọrun sọkalẹ wá, o sì yí okuta kuro l'ẹnu ọna iboji, o sì joko le e. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 24).

Nigbanâ ni awọn meji ninu awọn ọmọ-ẹhin Jesu lọ ni ijọ́ kanná si iletò kan t'a npè ni Emmausi, t'o jina si Jerusalemu n'iwọn ọgota stadia Nwọn mba ara wọn sọ̀rọ gbogbo nkan wọnyi t'o ṣẹ. O sì ṣe, nigbati nwọn mba ara wọn sọ, ti nwọn sì mba ara wọn rò, Jesu tikara-

larẹ̀ sì sunmọ wọn, o sì mba wọn rìn lọ. Ṣugbọn a ru wọn li oju, ki nwọn ki o máṣe lè mọ Ọ. O sì bi wọn lère wipe : Ọrọ kili ẹnyin mba ara nyin sọ l'ọ̀na, êhaṣe ti ẹnyin sì fi fajuro ? Ọkan ninu wọn t'a npè ni Kleofa sì dahùn o wí fun U pe : Alejo ṣá ni iwọ ni Jerusalemu, ti iwọ kò sì mọ ohun t'o ṣẹ nibẹ̀ li ọjọ́ wọnyi ? O sì bi wọn lère wipe, Kini ? Nwọn sì wipe : Niti Jesu ti Nasareti, ẹniti iṣe woli, ti o pọ̀ li iṣẹ ati ọ̀rọ n'iwaju Ọlọrun ati n'iwaju gbogbo enia, ati bi awọn olori alufa ati awọn àlàgba wa ti da a lẹbi ikú, ati bi nwọn ti kàn a mọ́ agbelebu. Bi o ṣe ti wa ni, awa reti pe on ni iba da Israeli nide ; lẹhin gbogbo nkan wọnyi oni li o di ijọ́ kẹta ti nkan gbogbo ti ṣẹ. Otitọ ni awọn obirin kan ninu awọn ti o wà pẹlu wa da wa nijì, ti nwọn lọ si iboji ni kutukutu, ti nwọn kò sì ti ri okú rẹ̀, nwọn wá wipe awọn sì ri iran awọn Angẹli ti nwọn wipe : O wà lâye. Ati awọn kan ti nwọn wà pẹlu wa lọ si iboji, nwọn sì rí i gẹgẹ bi awọn obiri ti wí ; ṣugbọn on tikararẹ̀ ni nwọn kò ri. Nigbanà ni O wí fun wọn pe : Ẹnyin ọmọ̀ ati ọlọkàn lilọra lati gbà gbogbo eyi ti awọn woli ti wí gbọ́ ! Kò yẹ ki Kristi kì o jiyà nkan wọnyi, bẹ̀ni kì o sì wọ̀ inu ogo rẹ̀ lọ bi ? O sì bẹ̀rẹ̀ lati Mose ati gbogbo awọn woli wá, o sì tumọ̀ nkan fun wọn ti a wí nipati ara rẹ̀ ninu gbogbo Iwe mimọ́. Nigbati nwọn sì sunmọ́ iletò ti nwọn nlọ, Jesu ṣe bi ẹnipe yio lọ siwaju. Ṣugbọn nwọn rọ̀ ọ, wipe : Ba wa duro, nitori o di ọjọ́ alẹ́, ọjọ́ sì kọja tan. O sì bá wọn wọ̀le lọ. O sì ṣe, bi o ti bá wọn joko tì onjẹ, o mu akara, o sure si i, o sì bù u, o sì fifun wọn.

Nighanâ ni oju wọn là, nwọn sì mọ ọ; o sì dì òfo loju wọn. Nwọn sì bá ara wọn sọ pe: Ọkàn wa kò ha gbiná ninu wa, nigbati o mbá wa sọ̀rọ li ọ̀na, ti o sì ntumọ̀ Iwe mimọ́ fun wa bi? Nwọn sì dide ni wakati nà, nwọn pada lọ si Jerusalemu, nwọn sì ba awọn apostoli mọkanla pejọ, ati awọn ti mbẹ̀ l'ọdọ wọn, nwipe: Oluwa jinde nitôtọ, o sì fi ara hàn fun Simoni. Lasikò ti wọn, nwọn sì rohin nkan ti o ṣẹ lọna, ati bi o ti dì mimọ̀ fun wọn ni bibù akara.

Ifitọrẹ. Angẹli Oluwa t'ọrun sọkalẹ wá, o sì wí fun awọn obiri pe: Tali ẹnyin nwá? Ojinde gẹgẹ bi o ti wí. Alleluia.

Adura. (O ri bakannâ bi ti ijọ́ ọdún Paska.

Komunioni. Oluwa jinde, O sì f'arahàn fun Piteru. Alleluia.

Adura. (O ri bakannâ bi ti ijọ́ ọdún Paska).

IJỌ ỌSẸ EKINI LẸHIN PASKA,

T'a npè ni QUASIMODO.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Bi ọmọ titun, alleluia, ki ẹ mà fẹ wara ẹmí ti kò li àbula. Alleluia, alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun alâbo wa, ki ẹ sì fi inudidùn kọrin iyìn si Ọlọrun Jakobu. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun Olodumare, fifun ni, ki awa ti o ti

ṣe ọdún Paska tán lè ma, tipasẹ ôre-ọfẹ rẹ, pa ìro ati ẹmí ọdún mímọ́ nâ mọ́ li iṣẹ ati li hihùwa wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Joh 5).

Olufẹ mi, ẹnikẹni t'a bí nipa ti Ọlọrun, o ṣẹgun aiye, eyi sì ni iṣẹgun ti o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ́ wa. Tani ẹniti o ṣẹgun aiye, bikoṣe ẹniti o gbagbọ́ pe Jesu ni Ọmọ Ọlọrun? Eyi li ẹniti o wá fi omi on ẹjẹ wẹ wa mọ́, ani Jesu-Kristi; kì iṣe ni kìki ipa omi, bikoṣe nipa omi on ẹjẹ. Ẹmí li o sì njẹri pe Kristi ni otitọ; nitoripe ẹni mẹta li o njẹri li ọrun, Baba, Ọrọ ati Ẹmi-Mímọ́, awọn mẹtẹta yi sì jasi ọkán. Awọn mẹta li o sì njẹri li aiye, Ẹmi, omi ati ẹjẹ, awọn mẹtẹta yi sì jasi ọkán. Bi awa ba gbà ẹrí enia, ẹrí Ọlọrun pọ̀ju: ṣugbọn Ọlọrun pâpa li o jẹri yi ti o pọ̀ju nipa ti Ọmọ rẹ̀: Ẹniti o gbà Ọmọ Ọlọrun gbọ́, o ni ẹrí Ọlọrun ninu ara rẹ̀.

Graduali. Alleluia, alleluia. Li ọjọ́ Ajinde mi li emi o ṣaju nyin lọ si Galili, ni Oluwa wí. Alleluia. Lẹhin ijọ́ mẹjọ ajinde rẹ̀, nigbati gbogbo ilẹkun ti sé tan, ni Jesu de, o sì duro làrin awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, o sì wipe: Alafia fun nyin. Alleluia.

Ihin rere (Joh. 20).

Nigbanâ, li alẹ ijọ́ kannâ, ti iṣe ijọ́ ekini ọsẹ, nigbati gbogbo ilẹkun ti sé tan, nibiti awọn ọmọ-ẹhin gbé pejọ sì, nitori ibẹ̀ru awọn Ju,

ni Jesu wọle, o sì duro lârin wọn, o sì wí fun wọn pe : Alafia fun nyin. Nigbati o sì wí bẹ tan, o fi ọwọ́ ati ìha rẹ̀ hàn fun wọn. Nigbanâ li awọn ọmọ-ẹhin yọ̀ nigbati nwọn ri Oluwa. Jesu sì tún wí fun wọn pe : Alafia fun nyin. Bi Baba mi ti rán mi, bẹ̀ gẹgẹ li emi sì rán nyin. Nigbati o sì ti wí eyi tan, o mí si wọn, o sì wí fun wọn pe : E gbà Emi-Mimọ́. Ẹṣẹ ẹnikẹni ti ẹnyin ba fi jì, a sì fi jì wọn ; ati ẹṣẹ ẹnikẹni ti ẹnyin ba sì da duro, a sì da wọn duro. Sugbọn Toma, ọkan ninu awọn mejila, ti a npè ni Didimu, kò wà pẹlu wọn, nigbati Jesu de. Nitorinâ awọn ọmọ-ẹhin iyokùn wí fun u pe : Awa ti ri Oluwa. Sugbọn o wí fun wọn pe : Bikoṣe pe emi ba ri apa iṣó li ọwọ́ rẹ̀, ki emi ki o ti ikâ mi bọ apa iṣó wọnyi. ki emi ki o sì tẹ ọwọ́ mi bọ ìha rẹ̀, ẹmi kì iyo gbagbọ́. Lẹhin ijọ́ mejọ, awọn ọmọ-ẹhin sì tún wà ninu ile, ati Toma pẹlu wọn ; nigbati gbogbo ilẹkun sì ti sé tan Jesu de, o sì duro lârin wọn, o sì wipe : Alafia fun nyin. Nigbanâ li o wí fun Toma pe : Mu ikâ rẹ wá nihin, ki o sì wò ọwọ́ mi ; mu ọwọ́ rẹ wá nihin, ki o sì tẹ ẹ bọ ìha mi, ki iwọ ki o má sì ṣe alaigbagbọ́ mọ́, sugbọn gbagbọ́. Toma dahùn, o sì wí fun u pe : Oluwa mi ati Olorun mi ! Jesu wí fun u pe : Nitoriti iwọ ti ri mi ni iwọ fi gbagbọ́ ; alabukún fun li awọn ti kò ti ri, ti nwọn sì ti gbagbọ́. Jesu sì ṣe ọpọlọpọ iṣẹ iyanu miran niwaju awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, ti a kò kọ́ sinu iwe yi Sugbọn iwọnyi li a kọ́, ki ẹnyin ki o lè gbagbọ́ pe : Jesu ni iṣe Kristi, Ọmọ Olorun, atipe ni gbigbà a gbọ́ ki ẹnyin ki o lè ni ìye nipa orukọ rẹ̀.

Ifitọrẹ. Angẹli Oluwa ti ọrun sọkalẹ wá, o sì wí fun awọn obirin pe : Tali ẹnyin nwá ? O jinde gẹgẹ bi o ti wí. Alleluia.

Adura t'a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi oju rere gbà ẹbo ti Ijọ awọn enia rẹ fi ayọ rù si Ọ ; bi Iwọ sì ti fun wọn li idi ayọ nla nà, fun wọn li eso alafia nlá pẹlu ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Mu ọwọ rẹ wá nihin ki o sì tẹ ẹ bọ apa isọ, alleluia ; ki iwọ ki o má ṣe alaigbagbọ mọ, ṣugbọn gbagbọ· Alleluia, alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Oluwa wa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ jẹ ki sakramenti mimọ yi ti Iwọ fi fun wa bi iranlọwọ atunṣe wa lè jẹ ọna atide ibi iye ti kò nipẹkun fun wa, l'igba isisiyi ati l'igba ti mbọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KEJI LẸHIN PASKA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ilẹ aiye kún fun ânu Oluwa, alleluia ; nipa ọrọ Oluwa li a da awọn ọrun. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹnyin olododo, ẹ mâ yọ ninu Oluwa ; o yẹ fun awọn ọlọkàn titọ nikan lati kọrin iyìn rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o tipasẹ irẹra silẹ Ọmọ rẹ gbé aiye dide kuro ninu idibajẹ rẹ, fun awọn onigbagbọ rẹ li ayọ ti kò nipẹkun; ki awọn ti Iwọ yọ kuro ninu ewu ikú ainipẹkun lè, tipa ânu rẹ, jẹ alafia ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Piteru 2).

Olufẹ mi, Jesu-Kristi jiyà nitori wa, ki ẹnyin ki o lè mâ topasẹ rẹ. Ẹniti kò dá ẹṣẹkẹṣẹ, ti a kò sì ri ọ̀rọ ẹtan l'ẹnu rẹ, Ẹni, nigbati nwọn nkẹgàn rẹ, ti kò sì pada kẹgàn, nigbati o jiyà, ẹniti kò sì fi ọ̀rọ dẹruba; ṣugbọn o fi ara rẹ le ẹniti iṣe idajọ rẹ li aiṣododo lọwọ. Ẹniti ontikararẹ fi ara rẹ rù ẹṣẹ wa de agbelebu, ki awa ti a di okú si ẹṣẹ lè dì âye si ododo; nipa ọgbẹ ẹniti a mu nyin larada; nitoriti ẹnyin ti dabi agutan ti o ti nṣìna, ṣugbọn nisisiyi ẹnyin pada wá sodọ Oluṣọ́-agutan ati sodọ Olutọju ọkàn nyin.

Graduali. Alleluia, alleluia. Awọn ọmọ-ẹhin mọ Oluwa Jesu nipa bibù akara, Alleluia, alleluia. Emi ni Oluṣọ́-agutan rere, mo si mọ awọn agutan mi, awọn agutan mi si mọ mi.

Ihin rere (Joh. 10).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn Farisi pe: Emi ni oluṣọ́ agutan rere. Oluṣọ́ agutan rere fi ẹmí rẹ fun awọn agutan rẹ. Ṣugbọn alagbaṣe, ti kì iṣe oluṣọ́-agutan, ẹniti awọn agu-

tan kì ise tirẹ, o ri ikoriko mbọ, o fi agutan silẹ. o sì sá lọ; ikorìko sì mu awọn agutan, o sì fọn wọn kákiri. Alagbaṣe sá lọ, nitoriti iṣe alagbaṣe, kò sì náni awọn agutan. Bi o ṣe ti emi ni, emi ni oluṣọ agutan rere, mo sì mọ awọn agutan mi, awọn agutan mi sì mọ mi, gẹgẹ bi Baba mi ti mọ mi, ti emi sì mọ Baba mi; mo sì fi ẹmí mi lelẹ fun awọn agutan mi. Emi sì ni awọn agutan miran, ti kì iṣe ti agbo yi; awọn li emi kò lè ṣe alaimu wá pẹlu, nwọn o sì gbohùn mi; agbo kan ati oluṣọ agutan kan ni yio sì wà.

Ifitọrẹ. Ọlọrun, Iwọ li Ọlọrun mi; ni kutukutu li emi o mâ ṣafẹri rẹ, emi o sì mâ gbé ọwọ́ mi soke si Ọ lati kigbe pè orukọ rẹ. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki ẹbọ ètutu mimọ́ yi, ki o mâ mu ọpọ ibukún rẹ ti o l'anfani wá sori wa nigbagbogbo, ki o lè fi agbara rẹ seso ninu wa, ti O nfihàn li ọna òrọ ijinlẹ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Emi li oluṣọ agutan rere Alleluia, emi sì mọ awọn agutan mi, awọn agutan mi sì mọ mi. Alleluia, alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi fun ni, ki awa t'a ri iye titun gbà nipa òre-ọfẹ rẹ. lè mâ ṣogo ninu ẹbun rẹ yi nigbagbogbo; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN ÂBO TI JOSEFU MIMỌ

(Ijọ́ ọsẹ kẹta lẹhin Paska.)

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa ni Oluranlọwọ́ ati Alàbo wa, niti rẹ li ọkàn wa yio yọ̀, awa sì gbẹ̀kẹle orukọ rẹ̀ mimọ́. *Ps.* Fi eti si ni, oluṣọ́ agutan Israeli, Iwọ t'o nda Josefu bi ọwọ́-agutan. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun, Iwọ t'o fi ipèse alailesọ fiyesi lati yàn Josefu mimọ́ bi ọkọ iyá rẹ mimọ́ julọ, fi fun wa, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, ki ẹniti a mbọlá fun bi alàbo wa laiye yi, ki awa lè ye lati ni I bi alagbawi wa l'ọrun rere, Iwọ t'o wà, t'o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu isọkan ti Ẹmi-Mimọ́ lai, Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

Adura ti ijọ́ ọsẹ.

Ọlọrun, Iwọ ti nfi imọlẹ otitọ rẹ hàn fun awọn ti mbẹ̀ ninu isìna, ki nwọn ki o lè pada bọ̀ sinu ipa ọna ododo, fifun gbogbo nwọn ti njẹwọ́ igbagbọ́ kristiani, ki nwọn ki o lè mâ yẹra kuro ninu ohun gbogbo ti o lodisi orukọ rere nà, ki nwọn ki o sì tọ̀ irú nkan wọnyi lẹhin ti o ba eyi nà ṣe dede ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Genes. 49).

Josefu ọmọkọnrin mi ndàgba, amâ dàgba si i nigbagbogbo, o sì dara lati wò; awọn ọmọbi-

rin sare kiri lori ogiri lati wò o. Ṣugbọn awọn tàfatàfa (arakọnrí rẹ̀) ba a ninujẹ pupọ̀, nwọn sì bá a jà, nwọn sì ṣe ilara si i. Ọkàn rẹ̀, bi ọrún ti a nà, gbẹkẹle Alagbara. A sì ṣẹ̀ awọn ẹwọn t'ọwọ́ t'ẹsẹ̀ rẹ̀ lati ọwọ́ Alagbara Jakobu wá; lati ibẹ̀ lọ li o di oluṣọ́ agutan ati agbara Israeli. Ọlọrun Baba rẹ yio jẹ Oluranlọwọ́ rẹ; Olodumare yio sì kún ọ fun ibukún lati òke ọrun, ibukún ibú-omi ti o wà ni isalẹ, ibukún ọmú ati eso t'inu. Ibukún baba rẹ yio jù ibukún ti o ti gbà lọdọ awọn baba rẹ̀ lọ; yio sì duro titi ifẹ̀ òke aiyeraiye o fi de. Ki ibukún wọnyi ki o dà sori Josefu, ati si atarí ẹniti a ya sọ̀tọ̀ làrin awọn arakọnrí rẹ̀.

Graduali. Alleluia, alleluia. Ninu ipọnju kipọnju ti nwọn kigbe pè mi, li emi o gbà wọn, emi o sì jẹ alàbo wọn titilai. Alleluia. Josefu jẹ ki awa lò ọjọ́ aiye wa ni mimọ́, ki âbo rẹ ki o sì mâ bò o titilai. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 3).

Nigbanâ li o sì se, nigbati a batisi gbogbo awọn enia, a batisi Jesu pẹlu, bi o sì ngbadura, ọrun sí silẹ, Ẹmi-mimọ́ sì sokalẹ sori rẹ̀ li awọ àra, ti o dabi àdaba, ohùn kan sì t'ọrun wá, t'o wipe : Iwọ ni ayanfẹ ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi. Jesu tikalarẹ̀ sì mbẹ̀rẹ̀ si to bi ẹni ìwọn ọgbọn ọdún, a sì fi i pè ọmọ Josefu.

Ifitọrẹ. Yìn Oluwa, iwọ Jerusalemu nitoriti o mu òpẹrẹ ẹnu-bode le, o sì bukún fun awọn ọmọ rẹ ninu rẹ. Alleluia, alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa ti a tipa âbo Ọkọ iyá rẹ mimọ́ julọ ti lẹhin nkigbe pè ânu rẹ, ki iwọ ki o dari ọkàn wa tobẹ, ti nwọn lè mâ gàn ohun gbogbo t'aiye yi, ti nwọn sì lè mâ fẹran rẹ nikan l'afẹtan; Iwọ t'o wà, t'o sì njọba, etc.

Iranti ijọ́ ọsẹ kẹta lẹhin Paska.

Oluwa, jẹ ki ohun ijinlẹ yi fun wa l'ôre-ọfẹ lati mu itara ifẹ wa fun ohun t'aiye yi tutu, ati lati tànná ifẹ si ohun t'ọrun rere ninu wa; Iwọ t'o wà, etc.

Komunioni. Jakobu sì bí Josefu Ọkọ Maria, lati ọdọ ẹniti a bí Jesu t'a npè ni Kristi. Alleluia.

Adura lẹhin komunion i.

Ọlọrun Oluwa wa, awa t'a fi sakramenti mimọ́ julọ bọ́, nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ pe, bi Iwọ ti mu wa yọ̀ âbo Josefu mimọ́, bẹni ki Iwọ ki o fi fun wa ki awa lè tipa itoye ati ẹbẹ rẹ̀, ye lati jẹ alabapín ninu ogo ọrun rere; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Adura ijọ́ ọsẹ kẹta.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki sakramenti yi ti awa gbà ki o mu wa lagbara nipa onjẹ ti ẹmí, ki o sì dâbobo wa nipa iranlọwọ́ ohun ara; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Ihin rere ikẹhin (Joh. 16).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Nìwọn ìgba diẹ, ẹnyin kì yio sì ri mi, ati nìwọn ìgba diẹ ẹwẹ, ẹnyin o sì ri mi, nitoriti emi nlọ sọdọ Baba mi. Nigbanâ ni omiran ninu awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ mbá ara wọn sọ pe : Kini eyi ti o wí fun wa yi : Nìwọn ìgba diẹ, ẹnyin kì yio sì ri mi, ati nìwọn ìgba diẹ ẹwẹ, ẹnyin o sì ri mi, nitoriti emi nlọ sọdọ Baba mi. Nitorinâ nwọn wipe : Kili eyi ti o wí yi : Nìwọn ìgba diẹ ? Awa kò mọ̀ ohun ti o wí. Ṣugbọn Jesu mọ̀ pe nwọn nfẹ̀ bi i lère, o sì wí fun wọn pe : Ẹnyin mbi ara nyin lère niti eyiti mo wipe : Nìwọn ìgba diẹ, ẹnyin kì yio sì ri mi, ati nìwọn igba diẹ, ẹnyin o sì ri mi. Lõtọ, lõtọ ni mo wí fun nyin pe : Ẹnyin o mâ sọkun, ẹnyin o sì mâ pohùn rere ẹkun, ṣugbọn awọn araiye yio mâ yọ̀. Inu nyin o sì bajẹ, ṣugbọn ibanujẹ nyin li ao sọ di ayọ̀. Nigbati obirin wà ninu irọbí, o wà ninu ibanujẹ nitoriti wakati rẹ̀ de ; ṣugbọn nigbati o ti bímọ tan, on kò ranti irora nâ mọ́ nitori ayọ̀ ti a bí enia si aiye. Bẹ̀ni pẹlu ẹnyin sì wà ninu ibanujẹ nisisiyi, ṣugbọn emi o tún ri nyin, ọkàn nyin yio sì yọ̀ kò sì si ẹnikẹni ti yio gbà ayọ̀ nyin l'ọwọ́ nyin.

IJỌ ỌSẸ KẸRIN LẸHIN PASKA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ korin titun si Oluwa, alleluia, nitoriti Oluwa ti ṣe ohun iyanu, alleluia ; o sì ti fi ododo rẹ̀ hàn loju awọn keferi.

Alleluia, alleluia. *Ps.* O ti gbà wa là nipa ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀ ati nipa apa rẹ̀ mímọ́. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ t'o mu awọn onigbagbọ́ rẹ ṣọkan li ẹmí ati l'ifẹ́, fifun awọn enia rẹ ki nwọn ki o lè mâ fẹ́ ohun t'Iwọ pa lasẹ fun wọn, ki nwọn sì mâ fẹ́ eyiti Iwọ ṣe ileri fun wọn pe, ninu onirùru ayipada aiye, ki ọkàn wa ki o lè duro ṣinṣin si ibiti ayọ̀ tòtọ́ gbé wà; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Jak. 1).

Ará mi olufẹ, gbogbo ẹbun rere ati gbogbo ẹbun pipé t'oke ọrun wá, o sì sọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá, lọdọ ẹniti kòsi yiyipada, bẹ̀ni kò si ojiji ayiparada. Nitori tinutinu l'o ti fi ọ̀rọ otitọ bí wa, ki awa ki o lè jẹ bi akọbí ninu awọn ẹdá rẹ̀. Ẹnyin mọ̀, ará mi olufẹ, nitori nâ ki olukuluku enia ki o mâ yara lati gbọ́, ki o lọra lati fohùn, ki o sì lọra lati binu, nitori ibinu enia ki imu ododo Ọlọrun ṣẹ. Nitorinâ ẹ fi gbogbo ìwa èri ati ọ̀pọ̀ iwa buburu silẹ, ki ẹnyin ki o sì fi ọkàn tutu gbà ọ̀rọ alọ́mọ ni, ti o lè gbà ọkàn nyin là.

Graduali. Alleluia, alleluia. Ọwọ́ ọ̀tún Oluwa nṣe agbara, ọwọ́ ọ̀tún Oluwa ti gbé mi ga li ogo, alleluia. Bi ati jí Kristi dide kuro ninu okú, kò n'ikú mọ́. Ikú kò lè ṣe Oluwa rẹ̀ mọ́. Alleluia.

Ihin rere (Joh. 16).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ ẹhin rẹ̀ : Emi nlọ sodọ ẹniti o rán mi, kò sì si ẹnikan ninu nyin t'o bi mi lère pe : Nibo ni Iwọ nlọ? Ṣugbọn nitori ti mo ti sọ nkan wọnyi fun nyin ibanujẹ kún ọkàn nyin. Ṣugbọn otitọ ni mo nsọ fun nyin : Anfani ni fun nyin bi mo ba lọ nitori bi emi kò ba lọ, Olutunu ni kì yio tọ̀ nyin wá ; ṣugbọn bi mo ba lọ, emi o rán a si nyin. Nigbati o ba sì de, yio fi oyé yé araiye nipa ti ẹ̀ṣẹ, nipa ti ododo ati nipa ti idajọ ; nipa ti ẹ̀ṣẹ, nitoriti nwọn kò ti gbà mi gbọ ; nipa ti ododo, nitoriti emi nlọ sodọ Baba mi, ti ẹnyin kì yio sì ri mi mọ ; ati nipa ti idajọ, nitoriti a ti ṣe idajọ alade aiye yi. Mo tún ni nkan pupọ̀ lati sọ fun nyin, ṣugbọn ẹnyin kò lè gbà wọn nisisiyi. Ṣugbọn nigbati Ẹmí otitọ ni ba de, yio kọ́ nyin li otitọ gbogbo ; nitori on kì yio sọ̀rọ ti ontikalarẹ̀, ṣugbọn ohunkohun ti o ba gbọ́, on ni yio mâ sọ, yio sì fi ohun ti mbọ̀ hàn nyin. On nâ o mâ yìn mi logo, nitoriti yio gbà ninu ohun ti iṣe ti emi, yio sì mâ fi hàn fun nyin.

Ifitọrẹ. Ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun, ẹnyin ilẹ aiye gbogbo ; ẹ kọrin si ọlá orukọ rẹ̀ ; ẹ wá gbọ́, gbogbo ẹnyin ti o bẹ̀ru Ọlọrun, emi o sì sọ ohun nla ti Oluwa ti ṣe fun ọkàn mi. Alleluia.

Adura ti a kà jẹ̀ẹ́.

Ọlọrun, Iwọ ti o ti ipa ibapín mimọ́ ninu ẹbọ yi sọ wa di alabapín ninu ọlánla ìwa-Ọlọ-

run rẹ, fifun ni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, pe bi a ti mọ otitọ rẹ, bẹni ki a lè tẹle e nipa ihùwa ti o yẹ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin

Komunioni. Nigbati Olutùnu, Ẹmí otitọ ni ba de, yio fi oyé yé araiye nipa ti ẹṣẹ, nipa ti ododo ati nipa ti idajọ.

Adura lẹhin komunioni.

Olorun, Oluwa wa, rán wa lọwọ, ki o sì jẹ ki a lè ti ipa sakramenti ti awa fi igbagbọ gbà, wẹ wa mọ kuro ninu ẹṣẹ wa, ki a sì yọ wa kuro ninu ewu gbogbo; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KARUM LẸHIN PASKA

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ mu ihó ayọ ró, ki ẹ sì jẹ ki a gbọ ọ nigbagbogbo. Alleluia. Ẹ rohin yí gbogbo aiye ká pe Oluwa ti gbà awọn enia rẹ là. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹ hó ihó ayọ si Olorun, ẹnyin ilẹ aiye gbogbo, ẹ korin si orukọ rẹ, ki ẹ sì yìn I logo. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olorun, lati ọdọ ẹniti ohun rere gbogbo ti wá, fifun ni, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ pe, nipa imisi rẹ ki a lè ma rò nkan wọnyi ti iṣe rere, ati pe labẹ itọju rẹ, ki a lè mà mu eyi nâ ṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Jak. 1-22).

Ẹnyin olufẹ ọwọ́n, ẹ mà fi ọ̀rọ nâ si ṣiṣe, ki ẹ má sì ṣe olugbọ́ nikan, ni titàn ara nyin jẹ; nitori ẹniti o ba gbọ́ ọ̀rọ nâ, ti kò ba sì fi i si ṣiṣe, o dabi ọkọnri ti nwò oju iyoju rẹ ninu digi; nitori nigbati o ti wò ara rẹ tán, o ba tirẹ lọ, lojukannâ o sì gbagbe bi on ti ri. Ṣugbọn ẹnit'o ba fi ikiyesi wò ofin pipé, ti iṣe ti omnira, t'o a ba sì duro ninu rẹ, ti kò sì ṣe olugbọ́ onigbagbe, ṣugbọn oluṣe iṣẹ nâ, on nâ ni yio ri alafia ninu iṣẹ rẹ. Bi ẹnikan ninu nyin ba rò pe on nsìn Ọlọrun, ti kò sì kó ahọn rẹ ni ijanu, ṣugbọn ti o ntàn ọkàn ara rẹ tikalarẹ jẹ, isìn rẹ jẹ asan. Isìn mimọ́ ati ailabawọn l'oju Ọlọrun Baba wa li eyi: ki a mâ bẹ awọn alaini-baba ati opó wò ninu ipọnju wọn, ki a sì pa ara wa mọ́ lailabawọn kuro ninu idibajẹ aiye yi.

Graduali. Alleluìa, alleluia. Jesu-Kristi ti jinde, o sì fi ara rẹ hàn fun wa, ti on ti fi ẹjẹ rẹ rà pada. Alleluia. Emi ti jade lati ọdọ Baba wá, mo sì ti wá si aiye; mo tún fi aiye silẹ, mo sì pada lọ sọdọ Baba mi. Alleluia.

Ihin rere (Joh. 16).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn Ọmọ-ẹhin rẹ pe: Lôtọ, lôtọ ni mo wí fun nyin, ohunkohun ti ẹnyin ba bère lọwọ́ Baba mi li orukọ mi, on yio fifun nyin. Titi di isisiyi ẹnyin kò ti bère ohunkohun li orukọ mi. Ẹ bère, ẹnyin o sì ri gbà, ki ayọ̀ nyin ki o lè pé.

Nkan wọnyi ni mo ti fi owe sọ fun nyin; akokò de, nigbati emi kì yio fi owe ba nyin sọ̀rọ̀ mó, ṣugbọn emi o sọ̀rọ̀ ti Baba fun nyin nigbangba. Li ọjọ́ nâ ẹnyin o bère li orukọ mi, emi kò sì wí fun nyin pe, emi o bère lọwọ́ Baba fun nyin, nitori Baba tikalarẹ̀ fẹ́ nyin, nitoripe ẹnyin ti fẹ́ mi, ti ẹnyin sì ti gbagbọ́ pe, lọdọ Ọlọrun ni mo ti jade wá. Emi ti jade lati ọdọ Baba wá, mo sì wá si aiye, mo tún fi aiye silẹ, mo sì lọ sọdọ Baba. Awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ wí fun U pe: Nisisiyi ni iwọ nsọ̀rọ̀ nigbangba, iwọ kò sì fi ọwe sọ̀rọ̀ mó. Nigba yi li awa mọ̀ pe iwọ mọ̀ ohun gbogbo, ati pe kò sì si idi kan mó fun ẹnikẹni lati bi ọ lère, nitori eyi nâ li awa gbagbọ́ pe, lọdọ Ọlọrun ni iwọ ti jade wá.

Ifitọrẹ. Ẹ fi ibukún fun Oluwa Ọlọrun wa, ẹnyin orile-ède, ki ẹ sì mu ni gbọ́ ohùn iyìn rẹ̀, on nâ l'o mu ẹmi mi wà lâye, ti kò sì jẹ ki ẹsẹ̀ mi yẹ̀. Ibukún ni fun Ọlọrun, ti kò kọ̀ adua mi silẹ, ti kò sì yí ânu rẹ̀ pada kuro lọdọ mi. Alleluia.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, tẹwọgbà adua ati ẹbọ awọn onigbagbọ́ rẹ̀, pe nipa isẹ̀ ifọkànsin daradara wọnyi, ki awa lè de ibi ogo ọrun; nipasẹ̀ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹ kọrin si Oluwa, alleluia, ẹ kọrin si Oluwa, ki ẹ sì fi ibukún fun orukọ rẹ̀; ẹ mâ fi igbalà rẹ̀ hàn lojojumọ.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Iwọ ti o fi agbara onjẹ ọrun bọ wa, fifun ni, ki awa ki o lè mâ bèrekiki nkan wọnyi ti o tọ ki awa sì lè ri eyiti a mbère gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ MIMỌ TI ASCENSIONI

Tabi Igoke rè ọrun ti Jesu-Kristi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹnyin arakọnri ará Galili, èṣe ti ẹnu fi yà nyin, ti ẹnyin ntẹjumọ oju ọrun? Alleluia ; gẹgẹbi ẹnyin ti ri I ti o ngoke lọ si ọrun, bẹni yio tún pada wá. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹnyin gbogbo orilẹ-èdè, ẹ ṣapẹ, ki ẹ sì fi ihó ayọ kọrin iyìn si Ọlọrun. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare, awa gbagbọ pe Ọmọ bíbi rẹ nikanṣoṣo Oluwa wa ti goke lọ si ọrun li oni yi, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ. fifun ni, ki awa pẹlu ki o lè fi ẹmí gbé inu ọrun rere ; nipasẹ Jesu-Kristi nâ Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iṣe awọn apost. 1).

Teofilu, ninu ihin ekini mi mo ti sọ ti ohun gbogbo ti Jesu ti ṣe, ti o sì ti kọni lati ibẹrẹ titi o fi di ọjọ ti a gbé E lọ si ọrun, lẹhin igbati o ti pasẹ, nipa Ẹmi-Mimọ, fun awọn apostoli ti o ti yàn ; awọn ẹniti o sì ti fi ara rẹ hàn fun bi alâye lẹhin ijiyà rẹ nipa ọpọlọpọ ẹri, ni fifi

ara rè hàn fun wọn niwọn ogoji ọjọ, ati ni biba wọn sọrọ ti ijọba Ọlọrun. Lẹhin eyi, o ba wọn jẹun, o si paṣẹ fun wọn pe, ki nwọn máṣe jade kuro ni Jerusalemu, ṣugbọn ki nwọn ki o duro de ileri Baba, ti ẹnyin ti gbọ li ẹnu mi (ni on wí). Nitori Johanu fi omi batisi, ṣugbọn ao fi Ẹmi-Mimọ batisi nyin lẹhin ọjọ diẹ si i. Nigbanâ ni awọn ti o pejọ bi I lère pe : Oluwa, Iwọ ki yio ha mu ijọba pada fun Israeli bi? O si wi fun wọn pe : Kì iṣe ti ẹnyin lati mọ ìgba tabi akokò ti Baba ti fi si agbara ara tikalarẹ. Ṣugbọn ẹnyin o gbà agbara Ẹmi-Mimọ, eniti yio sokalẹ wá sori nyin, ẹnyin o si mà ṣe ẹlẹri mi ni Jerusalemu, ati ni gbogbo Judea, ati ni Samaria, ati titi de opin ilẹ aiye. Nigbati o si ti wí nkan wọnyi tán, nwọn ri I ti a gbé soke, awọ-sanma si gbà a kuro loju wọn. Bi nwọn si ti tejumọ Ọ ti o ngoke lọ si ọrun, kiyesi i, awọn ọkọnri meji farahàn niwaju wọn, ti awọn ti aṣọ funfun, ti nwọn si wipe : Ẹnyin ọkọnri ará Galili, èse ti ẹnyin fi duro ti ẹnyin ntejumọ oju ọrun ? Jesu nâ yi, ti a gbà lọwọ nyin lọ si ọrun, yio tún papa wá, gẹgẹ bi ẹnyin ti ri I ti o nlọ si ọrun.

Graduali. Alleluia, alleluia. Ọlọrun Oluwa wa ti goke lọ làrin ihó ayọ ati irọ ipe. Alleluia. Gẹgẹ bi ni igbani lori òke Sinai, bẹni Oluwa ti goke si ibi giga, o si mu ọpọlọpọ igbekun ti on ti dá nide lọ sibẹ. Alleluia.

Ihìn rere (Mark 16-14).

Nigbanâ ni Jesu farahàn fun awọn mọkanla,

bi nwọn ti joko ti onjẹ, o sì ba wọn wí nitori aigbagbọ ati ọkàn lile wọn, nitoriti nwọn kò gbà awọn t'o ti ri I gbó, lẹhin igbati o ti jinde. O sì wi fun wọn pe : E lo si gbogbo aiye, ki ẹ sì mâ wâsu Ihin rere fun gbogbo ẹdá. Eniti o gbagbọ, ti o ba sì gbà ibatisi li ao gbalà ; sugbọn eniti kò gbagbọ li ao da lẹbi. Isẹ iyanu wọnyi ni yio sì mâ sìn awọn ti o gbagbọ lọ : Li orukọ mi ni nwọn o mà lé èsu jade ; nwọn o mà fi ède titún sọrọ ; nwọn o mâ gbé ejò l'ọwọ ; bi nwọn ba sì mu ohunkohun ti o l'oró, ki yio pa wọn l'ara ; nwọn o fi ọwọ le awọn alaisàn, nwọn o sì ri imularada. Nigbati Oluwa Jesu sì ti ba wọn sọrọ tan, a gbé E lọ soke ọrun, o sì joko l'ọwọ ọtún Ọlọrun. Sugbọn nwọn lọ, nwọn sì nwâsu nibi gbogbo, Oluwa sì mba wọn ṣisẹ, o sì mu ọrọ wọn l'agbara nipa isẹ iyanu to tẹle e.

Ifitọrẹ. Ọlọrun Oluwa wa ti goke lọ làrin ihó ayọ ati iró ipe. Alleluia.

Adura.

Oluwa, gbà ẹbun ti a rù l'ẹbọ si O nitori Igoke rẹ ọrun ti Ọmọ rẹ, ki o sì fi ojurere fi fun ni, ki a lè gbà wa kuro ninu ewu isisiyi, ki a sì lè de ibi ìye ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Komunioni. E korin iyìn si Ọlọrun, eniti o goke ori ọrun awọn ọrun ni ìha ìla ôrun. Alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare ati alânu, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, tifun ni pe, eyiti a ti gbà ninu sakramenti ti a lè ri, ki awa lè ri gbà ninu eso rẹ ti a kò lè ri ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ LẸHIN IGOKE RÈ ỌRUN TI JESU-KRISTI

Ipilẹsẹ ti Misa. Oluwa, gbọ́ ohùn mi, ti mo ti kigbe si Ọ. Alleluia, alleluia. Ọkàn mi ti wí fun Ọ pe : Mo ti wá oju rere rẹ; Oluwa, oju rere rẹ li emi o mâ wá, mâṣe yí oju rẹ pada kuro lọdọ mi Alleluia, alleluia. *Ps.* Oluwa li imọlẹ mi ati igbalà mi, aiya tani yio fò mi? Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraye, tifunmi, ki ifẹ wa lè mâ fà si isìn rẹ nigbagbogbo, ki a sì lè fi ọkàn aiṣẹtàn sìn olá nla rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Pet. 1-7).

Ẹ fi imoyé hùwa, ki ẹ sì mâ ṣora pẹlu adua. Ṣugbọn jù gbogbo rẹ lọ, ki ẹ ni ifẹ titilọ si ara nyin, nitori ifẹni bò ọpọlọpọ ẹṣẹ mọlẹ. Ẹ mâ ṣe ara nyin li alejò laikùn sinu. Bi oluku-

luku ti ri ẹbun gbà, bẹ̀ni ki ẹ mâ ṣòre nà fun ara nyin, bi iriju rere ti onirúru ôre-ọfẹ Ọlọrun. Bi ẹnikan ba nsọ̀rọ, ki o mâ sọ bi ọ̀rọ Ọlọrun. Bi ẹnikan ba nṣe iṣẹ Ọlọrun, ki o ṣe e gẹgẹ bi agbara ti Ọlọrun fifun u, ki a lè mâ yìn Ọlọrun logo li ohun gbogbo nipa Jesu-Kristi Oluwa wa.

Graduali. Alleluia, alleluia. Oluwa li ọba gbogbo awọn orilẹ-ède; Ọlọrun joko lori itẹ mimọ rẹ̀. Alleluia. Emi ki yio fi nyin silẹ li alaini-baba; emi nlọ, emi o si tún pada tọ̀ nyin wá, ọkàn nyin yio si yọ̀, Alleluia.

Ihin-rere (Joh. xv, 26).

Nigbanà ni Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe: Nigbati Olutunu nà ba de, ẹniti emi o rán si nyin lati ọdọ Baba wá, ani Ẹmi otitọ ni, ẹniti nti ọdọ Baba jade wá, on ni yio jẹri mi. Ẹnyin pẹlu yio si jẹri mi, nitoriti ẹnyin ti wà pẹlu mi lati ipilẹṣẹ wà. Nkan wọnyi ni mo ti sọ fun nyin, ki a má ba mu nyin ṣẹ̀. Nwọn yio lé nyin kuro ninu sinagogu (ibi apejọ awọn Ju fun isin Ọlọrun), ani akokò nà mbọ̀, ti ẹni kẹni ti o ba pa nyin yio rò pe on nṣe isin fun Ọlọrun. Nkan wọnyi ni nwọn o si ṣe si nyin, nitori nwọn kò mọ̀ Baba ati emi. Sugbọn nkan wọnyi ni mo ti wi fun nyin pe, nigbati wakati nà ba de, ki ẹnyin ki o lè ranti pe mo ti sọ wọn fun nyin.

Ifitọrẹ Ọlọrun ti goke lọ lârin ihó ayọ̀ ati iró ipe. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki ẹbọ alailabawọn yi ki o wẹ wa mọ, ki o si tú agbara ôre-ọfẹ ọrun sinu ọkàn wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Baba, nigbati mo wà pẹlu wọn, mo ti pa awọn ti Iwọ fifun mi mọ, alleluia. Ṣugbọn emi mbọ wá ọdọ rẹ nisisiyi: emi kò gbadura pe, ki Iwọ ki o lè mu wọn kuro li aiye yi, ṣugbọn ki Iwọ ki o lè pa wọn mọ kuro ninu ohun buburu. Alleluia, alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ fifunni, ki awa ti o kún fun ẹbun mimọ rẹ, ki a lè mâ dupẹ fun ọ titilọ nitori wọn; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ MIMỌ TI PENTEKOSTI

Tabi Isọkalẹ Ẹmi-Mimọ wá sori awọn Apostoli,

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹmí Oluwa ti kún gbogbo aiye, bi on sì ti ni ohun gbogbo ninu, o mọ ohunkohun ti a nwí. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ki Ọlọrun ki o dide, ki a sì tú awọn ọtá rẹ ka, ki awọn ti o korira rẹ ki o sì sá lọ kuro loju rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o kọ́ aiya awọn onigbagbọ rẹ loni yi nipa imọlẹ Ẹmi-Mimọ́, fifun wa nipa Ẹmi kannâ ki a lè ni iro rere ninu ohun gbogbo, ki a sì mâ yọ̀ nigbagbogbo ninu itunu mimọ́ rẹ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iṣe awọn apost. 2).

Nigbati ọjọ́ ọdún Pentekosti ti de, gbogbo awọn ọmọ-ẹhin ti pejọpọ̀ sibi kan. Lojiji nwọn sì gbọ́ iró nla ti o ti ọrun wá, gẹgẹ bi ti ẹfufu lile ti mbọ̀, o sì kún gbogbo ile nibiti nwọn gbé joko. Awọn ahọn bi ti iná ti o túka sì yọ sì wọn, nwọn sì ba le olukuluku wọn lori. Lojukannâ gbogbo wọn kún fun Ẹmi-Mimọ́, nwọn sì bẹrẹsi ti onirûru èdе sọ̀rọ, gẹgẹ bi Ẹmi-Mimọ́ ti fi ọ̀rọ sì wọn li ẹnu. Awọn Ju, olufọkànsìn enia ti gbogbo orilẹ-èdе ti mbẹ labẹ ọrun si wà ni Jerusalemu. Nigbati iróhin yi sì ti tàn kakiri, ọ̀pọ̀lọpọ̀ enia pejọ, nwọn sì damu nitoriti olukuluku gbọ́ ti nwọn nsọ̀rọ li èdе rẹ̀. Gbogbo wọn sì ṣe ha, ẹnu sì yà wọn, nwọn nwí fun ara wọn pe: Ará Galili kọ́ ni gbogbo awọn enia ti nsọ̀rọ wọnyi nsẹ bi? Ehatiṣe ti olukuluku wa ti ngbọ́ èdе rẹ̀ ninu eyiti a gbé bi wa si? Awọn ará Pertia, ará Media, ará Elamu, ati awọn ti ngbé ni Mesopotamia, Judea, Kappodosia, Pontu ati Asia, Frigia, Pamfilia, Egipti, ati apa ìha Libia ti o wà nitosi Sirene, ati awọn ti o ti Roma wá; awọn Ju ati awọn alawọṣe isìn Ju, awọn ará Krete ati ará Arabia, gbogbo wa gbọ́ ti nwọn nsọ̀rọ iṣẹ iyanu nla Ọlọrun li èdе wa.

Graduali. Alleluia, alleluia. Rán Ẹmi rẹ jade, ao sì tún dá wọn ; Iwọ o sì sọ oju ilẹ aiye di titun. Alleluia. Wá, Ẹmi-Mimọ́, k'o sì kún ọkàn awọn onigbagbọ́ rẹ, ki o sì daná ifẹ́ rẹ sinu wọn.

ORIN

1 Sọkalẹ, Ẹmi-Mimọ́ ,
Wá tàn'mọlẹ ọrun rẹ
Sin'ọkàn enia rẹ.

2 Wá, Baba ti talaka,
Wá, olufunni l'ẹbun,
Wá, imọlẹ ti ọkàn.

3 Iwọ l'olutunu wa,
Olugbé rere t'ọkàn,
Irọ̀run irora wa.

4 N'isẹ wa 'Wọ n'isimi,
L'oru iwọ l'itura.
L'omije 'wọ l'itunu.

5 Imọlẹ daradara,
Imọlẹ aiyeraiye,
Kes'ọkàn enia rẹ.

6 Laisi òre-ọfẹ rẹ,
Isẹ wa kò nilari,
Ihùwa wa sì baru.

7 Wẹ̀ eyit'o lèri mọ́,
Seri si eyit'o gbẹ,
K'o sì w'ọgbẹ wa jiná.

8 Yí eyit'o le l'ọkàn,
Mu ọkàn tutu gbona,
Ṣamòna fun aṣina.

9 Fun aw'onigbagbọ́ rẹ,
Ti ngbe ọkàn wọn le ọ,
L'awọn ẹbun meje rẹ.

10 F'ère fun'wà rere wọn,
Alafia at'ayọ̀
L'aiye ti mbọ̀ titilai. Amin.

Ihin rere (Joh. xiv. 23),

Nigbanà ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe: Bi enikan ba fẹ́ mi, yio pa ọ̀rọ̀ mi mọ́, Baba mi o si fẹ́ ẹ, awa o si tọ̀ ọ wá, awa o si ṣe ibugbé wa ninu rẹ̀. Eniti kò fẹ́ mi ni kò pa ọ̀rọ̀ mi mọ́; ati ọ̀rọ̀ nà ti enyin ti gbọ́, kì ṣe ti emi, sugbọn ti Baba mi ti o rán mi. Nkan wọnyi li emi ti sọ fun nyin, niwọn igbati mo wà pẹlu nyin. Sugbọn Olutunu nâ, ti ise Emi-Mimọ́, eniti Baba mi yio rán li orukọ̀ mi, on ni yio kọ́ nyin li ohun gbogbo, yio si tún rán nyin leti ohunkohun ti mo ti sọ fun nyin. Alafia ni mo ti silẹ fun nyin, alafia mi ni mo fifun nyin, kì ise gẹgẹ bi aiye ti imà fun ni ni mo fifun nyin. Ki ọkàn nyin ki o máṣe bajẹ, bẹ̀ni ki o má si ṣe bẹ̀ru. Enyin ti gbọ́ pe mo ti wí fun nyin pe: Emi-nlọ, emi o si tún pada tọ̀ nyin wá. Ibaṣe pe enyin fẹ́ mi, enyin iba yọ̀ nitoriti mo nlọ sodọ̀ Baba mi, nitoriti Baba mi tobi jù mi lọ. Emi si ti wí fun nyin tẹlẹ̀ nisisiyi ki o to de, pe, nigbati o ba de, ki enyin

ki o lè gbagbọ. Emi kì yio banyin sọ̀rọ pupọ̀ mọ́; nitori alade aiye yi wá, kò sì ni nkan kan lọdọ mi ti iṣe tirẹ̀, ṣugbọn nitori ki araiye ki o lè mọ̀ pe emi fẹ́ Baba, atipe emi sì ṣe gẹgẹ bi Baba ti fi aṣẹ fun mi.

Ifitọrẹ. Ọlọrun, fi ẹsè eyiti Iwọ ti ṣe ninu wa mulẹ; ninu tempeli rẹ ni Jerusalemu li awọn ọba yio mâ mu ọrẹ fun ọ wá.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, so ẹbun ti a rù l'ẹbọ si ọ dì mimọ́, ki o sì wẹ̀ ọkàn wa mọ́ nipa imọlẹ Emi-Mimọ́; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Lojijì nwọn gbọ́ iró nla ti o ti ọrun wá, gẹgẹ bi ti efufu lile ti mbọ̀, o sì kún gbogbo ile nibiti nwọn gbé joko, alleluia, lojukanná gbogbo wọn kún fun Emi-Mimọ́, nwọn sì nsọ̀rọ iṣe iyanu nla Ọlọrun. Alleluia, alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, fifunni, ki ida sinu ọkàn wa ti Ẹmi-Mimọ́, ki o wẹ̀ wọn mọ́, ki o sì mu wọn seso iṣẹ rere nipa sisẹ̀ri ôre-ọfẹ rẹ̀ sinu wọn; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

VENI CREATOR SPIRITUS

Wá, Ẹmi-Mimọ́ Elẹda,
Bẹ ọkàn enia rẹ wò,
K'o sì kún ọkàn t'iwọ dà
Fun ôre-ọfẹ mimọ́ rẹ.

Iwọ l'a npè l'Olutùnu,
Ẹbùn Ọlọrun t'o tobi,
Isun ìye, iná ọrun,
Ifẹ́ at'òróro mímọ́.

'Wọ l'ikà ọwọ́ Ọlọrun,
'Wọ kún ni f'èbun meje rẹ,
Gẹgẹ bi ileri Baba
Iwọ f'òrọ si wa lẹnu

Tàn imọlẹ rẹ s'oyé wa,
Dà ifẹ́ rẹ sin'ọkàn wa,
K'o fun ara wa ti kò le
Li agbara nigbagbogbo.

Lé ọtá kuro lọdọ wa,
K'o sì fun wa l'alafia
K'o sì mâ jẹ amònà wa,
K'awa lè yẹ èṣẹ silẹ.

Fun wa l'igbagbọ́ alâye,
K'o kọ́ wa lati mọ Baba,
Ọmọ at'Iwọ t'o jade
Latin 'awọn mejeji wá.

Ogo ni f'Ọlọrun Baba,
Ati fun Ọmọ, t'o jinde
Kuro ninu isà okú,
Ati f'Ẹmi-Mímọ́ lailai. Amin.

MONDAY TI ỌDUN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Akara alikama daradara ni Ọlọrun ti fi bọ awọn enia rẹ, ati oyin ti o ti inu okuta ṣàn wá ni on ti fi tẹ́ wọn lọrùn. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun ti iṣe alâbo wa, ẹ kọrin iyìn si Ọlọrun Jakobu. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o fi Ẹmi-Mimọ́ fun awọn apostoli rẹ, máṣe jẹ ki adua ti awọn enia rẹ fi irẹlẹ ọkàn gbà si ọ ki o jẹ asán, ki awọn ti iwọ ti pè si igbagbọ́ ki o lè jẹ alafia nipa inu rere rẹ; nitori Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iṣe awọn apost. 10).

Li ojọ́ nâ ni Piteru là ẹnu rẹ, o si wipe : Arakọnri mi, Oluwa ti pàṣẹ fun wa lati mâ wâsu fun awọn enia, ati mâ jẹri pe On li Ọlọrun yàn lati ṣe onidajọ âye on okú. On ni gbogbo awọn woli jẹri fun pe : Enikẹni ti o ba gbà a gbọ́, yio ri imukuro ẹṣẹ gbà li orukọ rẹ. Bi Piteru ti nsọ̀rọ lọwọ́, Ẹmi-Mimọ́ ba le gbogbo awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ nâ lori. Ẹnu si ya awọn onigbagbọ́ onilà ti o ti ba Piteru wá, nitoriti ôre-ọfẹ Ẹmi-Mimọ́ dà sori awọn keferi pẹlu, nitori nwọn gbọ́ ti nwọn nfi onirùru ède sọ̀rọ, ti nwọn si nyìn Ọlọrun logo. Nigbanâ ni Piteru dahùn wipe : Enikẹni ha le kọ́ omi ibatisi fun awọn ti o ti gbà Ẹmi-Mimọ́ bi awa bi? O si

pase ki a batisi wọn li orukọ Oluwa Jesu-Kristi. Lẹhin eyi, nwọn bẹ ẹ ki o ba wọn duro ni ijọ melokan.

Graduali. Alleluia, alleluia. Awọn apostoli nróhin iṣẹ iyanu nla Ọlọrun li onirùru ède.

Lẹhin eyi a kà : Sọkalẹ, Ẹmi-Mimọ, etc.

Ihin rere (Joh. 3).

Nigbanâ ni Jesu wí fun Nikodemu pe : Ọlọrun ti fẹ araiye tobẹ ti o fi Ọmọ bíbi rẹ nikanṣoṣo fun ni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ ki o má ba ṣegbé, ṣugbọn ki o ni iye ti kò nipẹkun. Nitori Ọlọrun kò rán Ọmọ rẹ si aiye lati da araiye lẹbi, ṣugbọn ki a lè gbà araiye là nipa rẹ. Ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ, a kò da a lẹbi. ṣugbọn ẹniti kò gbà a gbọ li a ti da lẹbi, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bíbi nikanṣoṣo ti Ọlọrun gbọ. Idi idalẹbi nâ ni pe : Imọlẹ ti wá si aiye, awọn enia si ti fẹ òkunkun jù imọlẹ lọ, nitoriti iṣẹ wọn buru. Nitori ẹnikẹni ti o ba nṣe buburu ni ikorira imọlẹ, kò si sùnmọ imọlẹ, ki a má ba da iṣẹ rẹ lẹbi. Ṣugbọn ẹniti o ba nṣe otitọ ni isùnmọ imọlẹ, ki iṣẹ rẹ lè farahàn, nitoriti a ṣe wọn gẹgẹ bi ti Ọlọrun.

Ifitọrẹ. Ọlọrun sán àrá lati òke ọrun wá, Ọga-ogo si mu ohùn rẹ hó, isun omi si bẹrẹsi hàn. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fi ânu sọ ẹbun

yi dì mimọ́, ati ni gbigbà ẹbọ ẹmí ti a rù si Ọ, ki o so wa dì ẹbọ ainipẹkun fun Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹmi-Mimọ́ yio kọ́ nyin li ohun-kohun ti mo ti sọ fun nyin. Alleluia, allelnia.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ran awọn enia rẹ lọwọ́, ki o si dâbobo awọn ti Iwọ fi sakramenti mimọ́ rẹ bọ́ kuro ninu ibinu ọ̀tá ti igbalà wọn; nipasẹ Jesu-Kristi wa Oluwa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN TI MẸTALỌKAN MIMỌ

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ibukún ni fun Ẹni-Mẹtalọkan Mimọ́, ati fun Iwà iṣọkan alailèpín; ao mâ yìn Ọlọrun logo, nitoriti o ṣànu fun wa. *Ps.* Oluwa, Oluwa wa, bawo ni orukọ rẹ ti ni iyìn to ni gbogbo aiye! Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o ti fun awọn iranṣẹ rẹ li ôre-ọfẹ ni ijẹwọ́ igbagbọ́ otitọ, lati mọ ogo Ẹni-Mẹtalọkan aiyeraiye, ati ni agbara Ọlá nla rẹ, lati foribalẹ fun Iwa iṣọkan rẹ; fifun wa, pe, nipa diduro ṣinṣin ninu igbagbọ́ yi, ki a lè mâ dâbobo wa nigbagbogbo kuro ninu gbogbo iponju; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura ijọ́ ọsẹ ekini lẹhin Pentekosti

Ọlọrun, Iwọ ti iṣe agbara awọn ẹniti ngbẹkẹle Ọ, ti ânu gbà adua wa, ati bi awa kò ti lè ṣe ohun rere kan lẹhin rẹ, nitori ailera ẹdá wa, fun wa li iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ pe, nipa pipa ofin rẹ mọ́ ki awa ki o lè mâ wù Ọ ni ifẹ ati ni iṣe, nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. 11).

A! Ijinlẹ isura ọgbọ́n ati imọ̀ Ọlọrun! Bawo ni idajọ rẹ ti jẹ alailemọ̀ to, ati bawo ni ọ̀na rẹ sì ti jẹ awamáridi to! Nitori tali o mọ̀ ìro Oluwa? Tabi tani iṣe igbimọ̀ rẹ? Tabi tali o tètekọ fifun u, ti ao sì san a pada fun? Nitori lati ọdọ rẹ, nipa rẹ, ati ninu rẹ li ohun gbogbo mbẹ: On ni ogo wà fun titilai. Amin.

Graduali. Olubukún ni Iwọ Oluwa, ti nwò titide isalẹ ibú, t'o sì joko lori Kerubîmu. Olubukún ni Iwọ li oju ọrun, Iwọ sì yẹ fun iyìn titilai. Alleluia. alleluia; Olubukún ni Iwọ, Oluwa Ọlọrun awọn baba wa, Iwọ sì yẹ fun iyìn titilai. Alleluia.

Ihin rere (Mat. 28).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe: Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi. Nitorinâ ẹ lọ, ki ẹ sì mâ kọ́ gbogbo orilẹ-ède, ki ẹ sì mâ batisi wọn li oruko Baba, ati Ọmọ, ati Ẹmi-Mimọ́, ki ẹ sì mâ kọ́ wọn lati mâ pa ohun gbogbo ti mo ti pa li aṣẹ fun nyin

mọ́. Ẹ sì kiyesi i, emi wà pẹlu nyin nigbagbogbo titide opin aiye.

Ifitọrẹ. Ibukún ni fun Ọlọrun Baba, ati fun Ọmọ bibi-nikanṣoṣo ti Ọlọrun, ati fun Ẹmi-Mimọ́ pẹlu, nitoriti o fi ânu rẹ̀ hàn fun wa.

Adura ti a kà jejẹ.

Oluwa, Ọlọrun wa, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, so hostia ti a rù lẹbọ si Ọdi mimọ́, ati nipa eyi nâ ki o so wa di ẹbọ yiyẹ fun Ọ titilai; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura t'ijọ́ ọsẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, tẹwọgbà ẹbọ yi ti a rù si Ọ, ki o si fifunni, ki o lè ṣe iranlọwọ́ titilọ fun wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹ jẹ k'a fi ibukún fun Ọlọrun, ki a si kọrin iyin rẹ̀ niwaju gbogbo ẹdá alâye, nitoriti o fi ânu rẹ̀ hàn fun wa.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Ọlọrun wa, jẹ ki sakramenti mimọ́ ti awa ti gbà, ati ijẹwọ́ Metalọkan mimọ́ ati aiyeraiye, ati ti Iwa iṣọkan rẹ̀ alailèpin ki o lè fun wa ni ôre-ọfẹ igbalà ara ati ti ọkàn wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura t'ijọ́ ọsẹ

Oluwa, bi awa ti kún fun ẹ̀bun nla rẹ, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, fifunni. ki awa lè ri ôre-ọfẹ igbalà ainipẹkun gbà, ki awa má sì ṣe dawọ-duro lati yin Ọ logo titilai ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Ihin rere ikẹhin (Luk. 6).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ẹ ṣe ânu, gẹgẹ bi Baba nyin ti ṣe ânu. Ẹ máṣe dani lẹjọ, a kì yio sì da nyin lẹjọ ; ẹ máṣe dani lẹbi, a kì yio sì da nyin lẹbi ; ẹ darijì, ao sì darijì nyin ; ẹ fifunni, ao sì fifun nyin ; osuwọ̀n daradara, akìmọlẹ, amìpọ, ati akúnwọ silẹ li ao dà si inu nyin, nitori osuwọ̀n nâ ti ẹnyin fi wọ̀n, li ao fi wọ̀n pada fun nyin. O sì pa owe yi fun wọn : Afọ́ju ha lè ṣe amọ̀na fun afọ́ju bi ? Awọn mejeji kì yio ha ṣubu sinu iho bi ? Ọmọ-ẹhin ki ijù oluwa rẹ̀ lọ, ṣugbọn olukuluku yio pé, bi o ba dabi oluwa rẹ̀. Ẹṣe ti iwọ nwò ẹ̀rún koriko ti mbẹ li oju arakọnri rẹ, ṣugbọn iwọ kò kiyesi igi àja ti mbẹ li oju ara rẹ ? tabi bawo li iwọ ti ṣe lè wí fun arakọnri rẹ pe : Arakọnri, jẹ ki emi ki o yọ ẹ̀rún koriko ti mbẹ li oju rẹ, nigbati iwọ tikalarẹ kò kiyesi igi àja ti mbẹ li oju ara rẹ, Iwọ agabagebe, tetekọ yọ igi àja jade kuro li oju ara rẹ, nigbanâ ni iwọ yio riran bi ati ṣe lè yọ ẹ̀rún koriko ti mbẹ loju arakọnri rẹ.

ỌJỌ MIMỌ TI KORPUS KRISTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Akara alikama daradara ni Ọlọrun ti fi bọ awọn enia rẹ, ati oyin ti o tinu okuta ṣàn wá li On ti fi tẹ wọn l'ọrun. Alleluia, alleluia. *Ps.* Ẹ hó ihó ayọ̀ si Ọlọrun ti iṣe alâbo wa, ẹ kọrin iyìn si Ọlọrun Jakobu. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun, Iwọ ti o fi iranti ijiyà rẹ silẹ fun wa ninu sakramenti t'o kún fun iyanu yi, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, fifun wa, ki awa lè bọlá fun ọrọ ijinlẹ mimọ́ ti ara ati ẹjẹ rẹ tobẹ, ti awa lè fi mọ eso idàndè rẹ li ọkàn wa nigba gbogbo, Iwọ t'o wà, ti o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu isọkan Ẹmi-Mimọ́, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (1 Kor. 11).

Ará mi, lọwọ́ Ọlọrun ni mo ti gbà eyini ti mo ti fifun nyin pe: Oluwa Jesu, li oru ọjọ́ nâ ti a ṣofofo rẹ̀, o mu akara, o dupẹ, o sì bù, o sì wí pe: Ẹ gbà, ẹ sì jẹ, eyiyi li ara mi, ti ao fifun pipa nitori nyin; ẹ mâ ṣe eyi li iranti mi. Gẹgẹ bẹ pẹlu o sì mu kalisi, lẹhin igbati o jẹun tán, o nwipe: Kalisi yi ni majẹmu titun li ẹjẹ mi; nigbakûgba ti ẹnyin ba nmu u, ẹ mâ ṣe eyi ni iranti mi. Nitori nigbakûgba ti ẹnyin ba njẹ akara yi, ti ẹnyin ba sì nmu kalisi, ẹnyin o fi ikú Oluwa hàn titi o fi de. Nitorinâ ẹnikẹni ti o ba jẹ akara yi, tabi ti o ba mu kalisi Oluwa yi laiyẹ, on o jẹbi ibajẹ ara ati ẹjẹ

Oluwa. Nje nitorinâ ki enia ki o wadi ara rẹ daju, bẹni ki o sì jẹ ninu akara nâ, ki o sì mu ninu kalisi nâ; nitoripe ẹnikẹni ti o ba njẹ akara nâ, ti o ba sì nmu kalisi nâ laiyẹ, o njẹ, o sì nmu ẹbi fun ara rẹ, nitoriti kò mọ iyàtọ ara Oluwa.

Graduali. Oju gbogbo ẹdá nwò ọ, Oluwa, Iwọ sì fun wọn li onjẹ wọn li akokò rẹ. Iwọ ṣí ọwọ́ rẹ, iwọ sì kún gbogbo ẹdá alâye fun ibukún rẹ. Alleluia. Ohun jijẹ li ara mi nitôtọ, ati ohun mimu sì li ẹjẹ mi nitôtọ. Ẹnikẹni ti o ba jẹ ara mi, ti o ba sì mu ẹjẹ mi, o ngbé inu mi, emi sì ngbé inu rẹ.

LAUDA, SION, SALVATOREM

1 Yìn Oluwa rẹ, Sioni,
K'o kọrin yìn Olugbala
At'Oluṣọ́ mimọ́ rẹ.

2 Yìn I bi iwọ ti lè ṣe to,
O rekọja gbogbo iyìn;
Iwọ kò lè yìn I to lai.

3 Akara t'o funni l'iye,
Ti a mâ fun wa lati jẹ,
L'a ṣe ọdún rẹ loni.

4 Li onjẹ alẹ ni Jesu
Fun awọn mejejila rẹ
L'onjẹ mimọ́ t'ọkàn yi.

5 E jẹ k'a mu ayọ̀ wa hó
Nipa orin didùn, t'o yẹ
Fun misteri t'isìn wa.

6 Nitori ọdún mimọ́ yi
Ran wa leti idásilẹ
Ti Ukaristi mimọ́.

7 L'asè kẹhin ti Jesu sè,
L'o fi Paska titun parọ́
Awóran Paska lailai.

8 Isìn wa rọ̀po ti lailai,
Otitọ lé ojiji lọ.
Imọlẹ gbìpo oru.

9 Eyiti Jesu-Kristi ṣe
L'onjẹ alẹ, ni on pasẹ
K'a mâ ṣe l'iranti rẹ̀,

10 Gẹgẹ bi ẹkọ́ mimọ́ rẹ̀,
A mâ yí agara pada
Di ẹran igbalà wa.

11 Nitori igbagbọ́ kọ́ ni
Pe, akara ati ọti
Dì ara ati ẹjẹ.

12 Eyit'a kò lè fojuri,
T'o sì rekọja oyé wa,
L'igbagbọ́ alâye gbà.

13 Labẹ aworan akara
Ati ọti, ti kò si mọ́,
L'ohun iyebiye wà.

14 Onjẹ l'ara, ohun mimu
L'ẹjẹ ; Jesu wà lodidi
Labẹ aworan kọkan.

15 Nigbati a pín hostia,
A gbà'ra Jesu lodidi
Labẹ ipin rẹ kọkan.

16 Bi ẹgbẹrun, tab'ẹnikan
Ba gbà A, ipin wọn dọgba ;
O kù silẹ f'ẹlomî.

17 Ẹni buburu bi rere
L'o gbà a, iye tabi ikú
Li ère ti nwọn o jẹ.

18 Ikú ni f'ẹni buburu,
Iyè ni f'enia rere,
B'ipin nwọn ti yatọ to !

19 K'igbagbọ rẹ k'o máṣe yẹ,
Iwọ gbà Jesu lodidi,
Nigbat'a pín hostia.

20 Aworan hostia l'a pín ;
Ara Jesu, t'a fifun ni,
Kò ṣe pín, kò sì dikùn.

21 Sawò akara Angẹli,
T'o di onjẹ fun arìnna ;
Akara t'aw'ọmọde ni ;
Kò yẹ k'a fifun ajá.

22 A ti ṣ'aworan rẹ tẹlẹ
Nipa irubọ t'Isaki,
Nipa t'ọd'agutan Paska,
Ninu iyẹfun Manna.

23 Olusọ́-agutan rere,
Jesu, onjẹ ìyc tôtọ,
Ṣânu, bọ́, k'o dâbobo wa,
Mu wa lọ s'ọrun rere.

24 Iwọ t'o mọ̀, t'o sì lè ṣe
Gbogbo. t'o f'ara rẹ bọ́ wa,
Sọ wa di alapèjẹ rẹ
L'ọrun rere n'ijọ́ kan. Amin.

Ihin rere (Joh. 6).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn Ju pe : Ohun jijẹ li ara mi nitôtọ, ati ohun mimu sì li ẹjẹ mi nitôtọ. Enikẹni ti o ba jẹ ara mi ti o ba sì mu ẹjẹ mi, o ngbé inu mi, emi sì ngbé inu rẹ. Gẹgẹ bi Baba alâye ti rán mi, ti emi sì wà nipa ti Baba, bẹ gẹgẹ ni ẹniti o jẹ mi, yio sì wà nipa mi. Eyi li onjẹ ti o ti ọrun sọkalẹ wà, kò dabi Manna ti baba nyin ti jẹ, ti nwọn sì kú; ẹnikẹni ti o ba jẹ onjẹ yi yio yè titilai.

Ifitọrẹ. Awọn saserdoti Oluwa rù turari ati akara lẹbọ si Ọlọrun, nitorinâ nwọn yio jẹ mimọ́ fun Ọlọrun wọn, nwọn kì yio sì bà orukọ rẹ jẹ. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, nipa ânu rẹ fun ijọ enia rẹ li ẹbun iṣọkan ati alafia, ti ẹbun yi ti a ru lẹbọ si Ọ fihàn l'ọna òrọ ijinlẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Nigbakugba ti ẹnyin ba njẹ

akara yi, ti ẹnyin ba sì nmu kalisi yi, ẹnyin o fi ikú Oluwa hàn titi o fi dé. Nitorinà ẹnikẹni ti o ba jẹ akara yi, tabi ti o ba mu kalisi Oluwa yi laiyẹ, on o jẹbi ibàjẹ ara ati ẹjẹ Oluwa. Alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa, mbẹbẹ lodọ, fifunni, ki a lè mà tẹ ifẹ wa lọrùn nipa riri ìwa-Ọlọrun rẹ titilai, ti gbigbà ara ati ẹjẹ rẹ iyebiye ṣe aworan rẹ li aiye yi, Iwọ ti o wà t'o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu isọkan Ẹmi-Mimọ, aiye ainipẹkun. Amin.

Lẹhin Misa, a kọrin « TANTUM ERGO »

1 K'a wólẹ, k'a foribalẹ
Fun sakramenti mimọ ;
Ki majẹmu lailai yẹra
Fun otitọ isìn yi.
Eyit'ailera oyé wa
Kò lè mọ, k'a mà gbagbọ.

2 Lai iyìn, ọlá, ibukún,
Agbara at'ogo ni
Fun Baba ati fun Ọmọ :
K'a sì mà f'ogo kannà
Fun Ẹmi-Mimọ, t'o jade
Latin'awọn mejeji wá. Amin.

IJỌ ỌSẸ KEJI LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa li alâbo mi, o mu mi jade lati inu ewu si ipo nla, o si gbà mi là, nitori inu rẹ̀ dùn si mi gidigidi. *Ps.* Emi o fẹ́ Ọ, Ọlọrun, agbara mi : Oluwa li alafẹ́hinti mi, ibi asálà ati olugbala mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, mu wa ni ibẹ̀ru ati ifẹ́ orukọ rẹ̀ titilọ, nitori iwọ kì itase lai lati ṣe iranlọwọ́ ati akoso awọn ti iwọ ti fi ẹsẹ̀ mulẹ̀ ninu ifẹ́ rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Joh 3).

Ẹnyin ará mi, ki ẹnu ki o máṣe yà nyin, bi aiye ba korira nyin. Awa mọ̀ pe awa ti kọja lati inu ikú sinu iye, nitoriti awa fẹ́ awọn arákọnri wa. Ẹnikẹni ti kò ba fẹ́, o ngbé inu ikú. Ẹnikẹni ti o ba korira arákọnri rẹ̀, apania ni ; ẹnyin sì mọ̀ pe kòsi apania ti o ni iye ainipẹkun abanigbé ninu rẹ̀. Nipa eyi li awa mọ̀ ifẹ́ Ọlọrun si wa, nitoriti o ti ẹmí rẹ̀ lelẹ̀ fun wa ; o sì yẹ ki awa fi ẹmí wa lelẹ̀ fun awọn arakọnri wa. Ẹniti o bá ohun ini ti aiye yi, ti o ba sì ri arákọnri rẹ̀ ninu aini, ti o si sé iyọ́nu rẹ̀ si i, bawo ni ifẹ́ Ọlọrun ti ṣe lè gbé inu rẹ̀? Ẹnyin ọmọde mi, ẹ máṣe jẹ ki a fi kiki ọ̀rọ̀ ati ahọn fẹ́, bikoṣe ni iṣe ati li otitọ.

Graduali. Ninu ipọnju mi, emi ti kigbe pè Oluwa, o si da mi lohùn. Oluwa, Ọlọrun wa,

gbà ọkàn mi lọwọ́ ete eké, ati lọwọ́ ahọn ètan. Alleluia, alleluia. Oluwa, iwọ li emi gbẹ̀kẹle, gbà mi lọwọ́ awọn ọtá mi, ki o sì gbà mi là. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 14).

Nigbanâ ni Jesu pa owe yi fun awọn Farisi pe : Ọkọnri kan sè àse alẹ nla kan, o sì pè enia pupọ́ si i. O sì rán iranṣẹ rẹ̀ li akokò àse alẹ lati lọ wí fun awọn alapèjẹ ki nwọn wá, nitori a ti mura nkan gbogbo tán. Ṣugbọn gbogbo wọn bẹ̀rẹsi fi ohùn kan ṣe awawi. Ekini wí fun u pe : Emi ti rà oko kan, emi kò lè ṣalaimálọ wò o ; mo bẹ̀ ọ, ṣe gafara fun mi. Ekeji sì wí pe : Emi ti rà malu mejimeji ọ̀na marun, emi sì fẹ́ lọ lati dán wọn wò, mo bẹ̀ ọ, ṣe gafara fun mi. Ẹkẹta sì wí pe : Emi ti gbeyawo, nitorinâ li emi kò ṣe lè wá. Iranṣẹ sì pada dé, o sì sọ gbogbo nkan wọnyi fun oluwa rẹ̀. Nigbanâ ni bâle ile binu, o sì wí fun iranṣẹ rẹ̀ pe : Fi kankan lọ si ita ati si opópo ilú, ki iwọ ki o sì mu awọn talaka, awọn aro, awọn afọju ati awọn amọkun wá si ihinyi. Iranṣẹ na si wí fun u pe : Oluwa, a ti ṣe bi iwọ ti wí tán, àye sì wà sibẹ̀sibẹ̀. Oluwa sì wí fun iranṣẹ pe : Jade lọ si gbangba ọ̀na ati si eti ọgba, ki o sì fi agbara mu wọn wọ̀le wá, ki ile mi ki o lè kún. Ṣugbọn mo wí fun nyin pe : Ẹnikẹni ninu awọn ti emi ti pè ki yio tọwò ninu àse alẹ mi.

Ifitọrẹ. Yi pada si mi, Oluwa, gbà ọkàn mi là, ki o sì gbà mi nipa ânu rẹ̀.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki ẹbọ, ti a ba yà si mimọ́ fun orukọ rẹ, ki o wẹ̀ ọkàn wa nù, ki o sì mu wa lọ siwaju si i ninu ihùwa bi ti ọrun lojojumọ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Emi o mâ kọrin si Oluwa, nitoriti o kún mi fun ôre, emi o sì mâ kọrin iyìn si orukọ Oluwa Ọga-ogo julọ.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, bi awa ti gbà ẹbun mimọ́ rẹ, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, fifunni pe, nipa gbigbà sakramenti mimọ́ yi nigbakùgba, ki eso igbalà wa ki o lè mâ pọ̀ si i; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ MIMỌ TI ỌKÀN MIMỌ JULỌ TI JESU

Ọdún yi bọ̀ si Friday kini ti o tẹle ọjọ́ Korpus Kristi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. On o ṣânu gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ânu rẹ̀, nitori ọkàn rẹ̀ kì igàn awọn ọmọ enia, bẹ̀ni kì sì ṣa wọn tì: Oluwa ṣe rere fun gbogbo awọn ti ngbẹ̀kẹle E, fun ọkàn ti o ṣafẹri rẹ̀. *Ps.* Emi o mâ kọrin ânu Oluwa lailai, lati irandiran. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifunni pe, nipa ṣiṣogo ninu Ọkàn mimọ julọ ti Ọmọ rẹ olufẹ, ati nipa ṣiṣe iranti awọn ọpọlọpọ ọrẹ ifẹ nla rẹ si wa, ki awa ki o lè mọ iṣẹ ati eso didùn wọn li ọkàn wa; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Isai 6).

Oluwa, emi o yin Ọ, nitori iwọ ti binu si mi, ṣugbọn ibinu rẹ ti yí kuro, iwọ sì tù mi ninu. Kiyesi i, Ọlọrun mi ni Olugbala mi; emi o hùwa ni igbẹkẹle, emi kì yio sì bẹru; nitori Oluwa ni agbara ati ogo mi. ontikalarẹ sì di igbalà mi. Ẹnyin yio ti tayọtayọ pọnmi lati inu kanga Olugbala wá. Li ọjọ nã ẹnyin sì wí pe: Ẹ yin Oluwa, ki ẹ sì kigbe pè orukọ rẹ. Ẹ sọ iṣẹ rẹ dì mimọ lârin awọn enia. Ẹ ranti pe orukọ rẹ tobi. Ẹ korin si Oluwa, nitoriti o ṣe ohun didara; ẹ sọ eyi dì mimọ ni gbogbo aiye. Ile Sioni, hó ihó ayọ ki o sì yin Ọlọrun, nitori Ẹni titobi, Ẹni mimọ Israeli mbẹ lârin nyin.

Graduali. Gbogbo ẹnyin ti nkoja li ọna yi, ẹ wò o, ki ẹ sì ri bi ibanujẹ kan ba wà bi ibanujẹ mi. Fifẹ ti o ti fẹ awọn tirẹ, o fẹ wọn titide opin. Alleluia, allelnia. Ki ẹ mã kọ ẹkọ ti emi, nitori ọlọkàn tùtu ati onirẹlẹ li emi; ẹnyin o sì ri isimi fun ọkàn nyin. Alleluia.

Ihin rere (Joh. 19).

Nigbanâ, nitoriti iṣe ọjọ́ ipalẹmọ, ki awọn okú ki o máṣe wà lori agbelebu ni ọjọ́ isimi, nitori ọdún nla ni ọjọ́ isimi nâ, ni awọn Ju bẹ Pilatu ki o jẹ ki a lè ṣẹ́ egungun itàn wọn, ki a sì lè gbé wọn kuro. Nigbanâ ni awọn ọmọ-ogun de, nwọn sì ṣẹ́ egungun itàn ti ekini ati ti ekeji, ti a li kàn mọ́ agbelebu pẹlu Jesu. Ṣugbọn nigbati nwọn de ọdọ Jesu, ti nwọn sì ri pe, o ti kú tán, nwọn kò ṣẹ́ egungun itàn rẹ̀, ṣugbọn ọkan ninu awọn ọmọ-ogun nâ fi ọ̀kọ̀ là a li ẹgbẹ, lojukanmâ èjẹ ati omi sì tú jade. Ẹniti o ri i, jẹ́rí rẹ̀, otitọ̀ sì li ẹ́rí rẹ̀.

Ifitọrẹ. Fi ibukún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbagbe gbogbo ôre rẹ̀; ẹniti o fi ohun didara tẹ́ ifẹ́ rẹ lọrùn. Alleluia.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, dâbobo awa ti o rù ẹbọ rẹ si Ọ, ki o sì daná ifẹ́ mimọ́ rẹ sinu ọkàn wa, ki nwọn ki o lè jẹ onitara gbigbona julọ lati sìn Ọ; Iwọ ti o wà. ti o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba, ninu iṣọkan Ẹmi-Mimọ́, aiye ainipẹkun. Amin.

Komunioni. Ọkàn mi ti reti kìki ẹgàn ati oṣì, emi sì woye fun ẹniti yio bá mi kânu, ṣugbọn kòsi; emi sì woye fun olutùnu kan, emi kò sì ri. Alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Bi a ti fi ayọ̀ t'o kún fun alafia, ati sakra-

menti olufunni li ìyc bọ́ wa, awa mbèbẹ lọdọ rẹ, Oluwa Ọlọrun wa ti iṣe ọlọkàn tùtu ati onirẹlẹ, ki o lè wù Ọ lati wẹ ọkàn wa nù kuro ninu gbogbo abawọ́n èṣẹ, ati lati mâ mu wa korira ogo asan ati igberaga ti aiye yi sibèsibè; Iwọ ti o wà, etc.

(A suivre).

TABLE

Pages

Quelques principes Grammaticaux de la Langue Fang 1

IWE ADURA LATI GBỌ MISA

Adua alẹ 72
Adua Angẹli 70
Adua lẹhin Misa 78
Adua nisaju ijẹwọ ẹṣẹ ati iwadi ọkàn ... 80
Adua nisaju ati lẹhin onjẹ 71
Adua ojojumọ ti Misa 86
Adua Owurọ 65
Adua si Ẹmi-Mimọ 80
Angẹlus 71
Asperges me 84
Awọn isẹ fun komunioni 81
Ifihàn akokò ti ọdún mimọ 62
Ilana-isìn Misa 57
Isẹ ojọ Kristiani 77
Litani Maria mimo 74

Pages.

Litani orukọ mimọ́ ti Jesu 68
Memorare..... 76
Ọjọ́ ọsẹ ekini ti Adfenti..... . 126
— ekeji — 130
— ẹkẹta — 134
— ẹkẹrin — 136
Misa l'ọganjọ 139
Ọdún Ibí Jesu-Kristi. Misa l'afẹmọjumọ. 141
Misa l'ojó..... 144
Oj ọdún Stefani mimọ́..... 146
Ọjọ́ ọdún Johanu mimọ́..... 150
Ọjọ́ ọsẹ lẹhin Ibí Jesu-Kristi..... .. 152
Ọjọ́ ọdún Ikọla Jesu-Kristi..... 154
Ọjọ́ Epiphany 157
Ọjọ́ ọsẹ ekini lẹhin Ifarahàn Jesu-Kristi. 160
Ọjọ́ ọsẹ ekeji lẹhin — — .. 163
Ọdún Orukọ mimọ́ Jesu-Kristi..... 166
Ọjọ́ ọsẹ kẹta lẹhin Ifarahàn Jesu-Kristi. 169
Ọjọ́ ọsẹ kẹrin — — .. 172
Ọjọ́ ọsẹ karun — — .. 173
Ọjọ́ ọsẹ kẹfa — — .. 176
Ọjọ́ ọsẹ Septuagesima 178
— Seksagesima..... 182
— Quinquagesima 186
Ọjọ́ ekini Igba-àwẹ..... 190

Pages.

Ọjọ́ ọsẹ ekini n'Igba-àwẹ..... 196
Ọjọ́ ọsẹ ekeji — 199
Ọjọ́ ọsẹ ẹkẹta — 202
Ọjọ́ ọsẹ ẹkẹrin — 206
Ọjọ́ ọsẹ ti Ijiyà Oluwa. 209
Ọjọ́ ọsẹ ti Mariwo..... 212
Ọjọ́ ẹkarun ti ọsẹ mimọ́..... 226
Ọjọ́ ẹkẹfa ti ọsẹ mimọ́..... 230
Ọjọ́ ekeje ti ọsẹ mimọ́..... 243
Ọjọ́ ọdún ti Paska..... 246
Ọjọ́ ekini lẹhin Paska..... 250
Ọjọ́ ọsẹ ekini — 253
Ọjọ́ ọsẹ ekeji — 256
Ọjọ́ ọdún Abo ti Josefu mimọ́..... 259
Ọjọ́ ọsẹ kẹrin lẹhin Paska..... 262
Ọjọ́ ọsẹ karun lẹhin Paska..... 265
Ọjọ́ ti Ascensioni (Igoke ọrun Jesu-Kristi) 268
Ọjọ́ ọsẹ lẹhin Ascensioni..... 271
Ọjọ́ ti Pentekosti (Isọkalẹ Ẹmi-Mimọ́).. 273
Ọjọ́ ekini lẹhin Pentekosti..... 279
Ọjọ́ ọdún ti Metalọkan mimọ́..... 281
Ọjọ́ ọdún ti Korpus Kristi..... 285
Ọjọ́ ọdún Ọkàn mimọ́ ti Jesu..... 293
Awọn ọjọ́ ọsẹ lẹhin Pentekosti..... .. 291
Misa fun awọn okú..... 117

ORIN

Pages.

Dies iræ 119
Lauda Sion 286
Libera me..... 122
O Filii et filiæ..... 249
Pange lingua... Lauream..... 241
Veni Creator 277
Veni Sancte Spiritus 275
Vexilla Regis..... 242
Victimæ Paskali 247

Alençon. — Typographie E. Renaut-De Broise.

ACTES

DE LA

SOCIÉTÉ PHILOLOGIQUE

TOME XXV. — ANNÉE 1896.

10e *de la nouvelle série.*

Alençon, imp. Renaut-De Broise, place d'Armes.

ACTES

DE LA

SOCIÉTÉ PHILOLOGIQUE

(Organe de l'Œuvre de Saint-Jérome)

TOME XXV

(10e de la nouvelle série)

ANNÉE 1896

PARIS
LIBRAIRIE C. KLINCKSIECK
11, rue de Lille, 11.

1897

ADURA LATI GBỌ́ MISA

Suite.

IJỌ ỌSẸ KẸTA LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Wò mi, Oluwa, ki o sì ṣânu fun mi, nitoriti mo jẹ talaka ati ẹni-ikòsilẹ. Wò irẹlẹ ati osì mi, ki o sì dari gbogbo ẹ̀ṣẹ ji mi, Ọlọrun mi. *Ps.* Oluwa mi. iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si; Ọlọrun mi, emi gbẹ̀kẹle ọ, lai máṣe jẹ ki emi dâmu. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, alâbo gbogbo awọn ti o gbẹ̀kẹle Ọ, laisi ẹniti agbara ati ìwa mimọ́ kò lè si ninu enia, jẹ ki ânu rẹ sì wa, ki o mà pòsi i, pe, labẹ akoso ati itọ́na rẹ ki awa ki o lè là ohun ini ti aiye yi koja tobẹ̀, ti a kì yio padanù ohun ini ọrun ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Epistoli (1 Piteru 5).

Ẹnyin olufẹ mi, ẹ rẹ̀ ara nyin silẹ labẹ ọwọ́ agbara Ọlọrun, ki on ki o lè gbé nyin leke li akokò ibẹ̀wò rẹ̀; ẹ mà kó gbogbo aniyàn nyin le e lọwọ́, nitoriti o nṣe aniyàn nyin. Ẹ mâ wà

lairekọja, ki ẹ sì mà ṣọ́ra, nitori èṣu ọtá nyin nrin kakiri yí nyin ká, bi kiniun ti nké ramuramu, o sì nwá ẹniti yio paje; ẹniti ki ẹnyin ki o kojujasi nipa diduro ṣinṣin ninu igbagbọ́; ki ẹnyin ki o sì mọ pe ipọnju kannà mbá awọn arakọnri nyin ti o wà li aiye. Ṣugbọn Ọlọrun ôre-ọfẹ gbogbo, ti o pè wa sinu ogo rẹ̀ ti kò nipẹkun nipa Kristi Jesu, nigbati ẹnyin ba ti jiyà nigba diẹ, yio ṣe nyin li asepé, yio fun nyin l'agbara, yio fi ẹsẹ̀ nyin mulẹ. On ni ogo ati ijọba mbẹ fun lai ati lailai. Amin.

Graduali. Kó âjo rẹ lọ si inu Oluwa, on ni yio bọ́ ọ. Nigbati emi ti kigbe pè Oluwa, o ti gbohùn mi nipa gbigbà mi lọwọ́ awọn ọtá mi. Alleluia, alleluia. Ọlọrun li onidajọ́ olododo, alagbara, ati onisùru, ti kì ibinu lojojumọ. Alleluia.

Ilàn rere (Luk. 15).

Nigbanâ ni awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ sunmọ́ Jesu lati gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀. Awọn Farisi ati awọn akọwe sì nkùn wipe: Ọkọnri yi ngbà awọn ẹlẹṣẹ, o sì mba wọn jẹun. Jesu sì pa owe yi fun wọn wí pe: Ọkọnri wo ninu nyin, ti o ní ọgọrun agutan, ati bi on ba sọ ọkan nù ninu wọn, ti kì yio fi mọkandilọgọrun iyokù silẹ ni aginjù, kì yio sì tọṣe eyiti o nù lọ, titi yio fi ri i. Nigbati o sì ri i tán, o gbé e le ejika rẹ̀ ti on ti ayọ̀. Nigbati o sì de ile, o pè awọn ọrẹ́ ati aladugbo rẹ̀ jọ, o sì nwí fun wọn pe: E ba mi yọ̀, nitoriti mo ri agutan mi, ti o ti nù. Mo wí fun nyin, bẹ̀ gẹgẹ ni ayọ̀ yio wà li ọrun rere nitori ẹlẹṣẹ kan t'o ronupiwada jù nitori olo-

dodo mọkandilọgọrun lọ, ti kò ni ironupiwada fi ṣe. Tabi obirin wo li o ní tọrọ mẹwa, bi o ba sọ ọkan nù, ti kì yio tàn fitila, kì yio sì gbá ile, kì yio sì wá a lesọlesọ titi yio fi ri i. Nigbati o sì ri i, o pè awọn ọrẹ ati aladugbo rẹ jọ, o wí pe : Ẹ ba mi yọ̀, nitoriti mo ri tọrọ nã ti mo ti sọnù. Mo wí fun nyin, bẹ̀ gẹgẹ ni ayọ̀ yio wà lârin awọn Angẹli nitori ẹlẹṣẹ kan ti o ronupiwada.

Ifitọrẹ Awọn ti o mọ̀ orukọ rẹ, nwọn gbẹkẹle Ọ, Oluwa, nitori iwọ kò ti ikọ̀ awọn ti nṣe afẹri rẹ silẹ. Ẹ kọrin iyìn si Oluwa ti ngbé inu Sioni, nitori on kò gbagbe adua awọn talakà.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi ojurere wò ẹbọ ijọ enia rẹ ti o ngbadua si Ọ, ki o sì fun awọn onigbagbọ̀ rẹli ôre-ọfẹ lati mâ ṣe alabapin ninu rẹ̀ pẹlu iwa mimọ̀ li ọkàn nigbagbogbo, ki nwọn ki o lè ri igbalà ainipẹkun gbà ninu rẹ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Mo wí fun nyin pe ayọ̀ wà lârin awọn Angẹli nigbati ẹlẹṣẹ kan ba ronupiwada.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki asè mimọ̀ rẹ ti awa ti jẹ ki o fun wa li iye titun, ki o sì ṣe ètutu fun èṣẹ wa, ki o sì mu wa yẹ lati jẹ eso ainipẹkun ti ânu rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸRIN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa li imọlẹ ati igbalà mi; tali emi o bẹ̀ru? Oluwa li âbo ẹmí mi; aiya tali o fò mi? Awọn ọtá mi, ti o pọ́n mi loju, nwọn dì alailera, nwọn sì ṣubu. *Ps.* Bi ogun tilẹ dotì mi, aiya mi kì yio fò. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fifunni, ki a lè ṣe ilana ipa ọ̀na aiye yi fun alafia wa labẹ ijọba rẹ; ki ijọ-enia rẹ ki o sì lè mâ fi ayọ̀ ati ifaiyabalẹ sin Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. VIII, 18).

Arákọnri, mo mọ̀ dajudaju pe ijiyà igba isisiyi kò yẹ lati fi ṣe akawe ogo ti nbọ̀, ti ao fihàn ninu wa. Nitori ẹdá nfi ifojusọ̀na durode ifihàn awọn ọmọ Ọlọrun. Nitori a tẹ̀ ori ẹdá ba fun asán, kì iṣe ifẹ́ rẹ̀, ṣugbọn nitori ẹnitio tẹ̀ ori rẹ̀ ba fun u, ni ireti pe ao gbà ẹdá tikalarẹ̀ kuro lọwọ́ itẹriba fun idibajẹ sinu omnira ogo awọn ọmọ Ọlọrun. Nitoriti awa mọ̀ pe gbogbo ẹdá li o nkerora, ti o sì nrọbi pọ̀ titi o fi di isisiyi. Kì si ṣe awọn nikan, ṣugbọn awa tikalawa pẹlu, ti o ni akọ́so Ẹmí, ani awa tikalawa nkerora ninu ara wa, awa ndurode isọdọmọ Ọlọrun, ti iṣe idande ara wa.

Graduali. Dari ẹ̀ṣẹ wa jì wa, Oluwa, ki awọn keferi má ba wí pe: Nibo ni Ọlọrun

wọn wà ? Ràn wa lọwọ́, Ọlọrun Olugbala wa, ki o sì gbà wa là nitori ogo orukọ rẹ. Alleluia, alleluia. Ọlọrun, iwọ ti o joko lori itẹ́, ti o sì ṣe idajọ ododo, jẹ́ àbo awọn talakà ninu ipọnju wọn. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 5).

Nigbati awọn enia sumọ́ Jesu lati gbọ́ ọ̀rọ Ọlọrun, ti o sì duro leti adagún Genesareti. o ri ọkọ̀ meji ti nwọn gunlẹ leti adagún, ṣugbọn awọn apeja sokalẹ kuro ninu wọn, nwọn nfọ̀ àwọn wọn. O sì wọ̀ okan ninu awọn ọkọ̀ nâ ti iṣe ti Simoni, o sì bẹ̀ ẹ ki o tì i sẹhin diẹ kuro ni ilẹ. O sì joko, o sì nkọ́ awọn enia lati inu ọkọ̀. Bi o ti dawọduro lati sọ̀rọ, o wí fun Simoni pe : Tì si ibú, ki ẹ sì jù àwọn nyin sisalẹ lati peja. Simoni dahùn, o sì wí fun u pe : Olukọ́ni, gbogbo oru aná li awa fi ṣisẹ, awa kò sì mu nkan, ṣugbọn nitori ọ̀rọ rẹ, emi o jù àwọn nâ. Nigbati nwọn ti ṣe eyi, nwọn kó ọ̀pọ eja. tobẹ̀ ti àwọn wọn fi yà ; nwọn sì ṣapẹ̀rẹ sì ẹgbẹ wọn, ti o wà li ọkọ̀ keji, ki nwọn ki o wá lati ràn wọn lọwọ́. Nwọn sì wá, nwọn kún ọkọ̀ mejeji, tobẹ̀ ti nwọn fi bẹ̀rẹsì rì. Nigbati Simoni Peteru ri i, o wólẹ lẹba ẹsẹ̀ Jesu, o wí pe : Oluwa, lọ kuro lodọ̀ mi, nitori ẹlẹṣẹ ni mi. Nitori ẹnu yà a, ati gbogbo awọn ti mbẹ pẹlu rẹ̀ fun pipa eja ti nwọn pa, bẹ̀ sì ni ẹnu yà Jakọbu ati Johanu, awọn ọmọ Sebede, ti iṣe alabápa Simoni. Jesu sì wí fun Simoni pe : Máṣe bẹ̀ru, lati isisiyi lọ iwọ o mâ mu enia Nigbati nwọn sì mu ọkọ̀ wọn de ilẹ nwọn fi nkan gbogbo silẹ, nwọn sì tọ̀ ọ lẹhìn.

Ifitọrẹ. Tàn imọlẹ si oju mi, Oluwa, ki emi ki o má ba sùn orun ikú, ati ki ọtá mi ki o má ba wí pe : emi ti ṣẹgun rẹ̀.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ ti a ru si Ọ ki o tù Ọ ninu, ati nipa ànu rẹ ki o sì fi agbara ví ifẹ́ ọlọtẹ wa pada si Ọ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa li alafẹhintì mi, ibi asálà mi ati olugbala mi ; Ọlọrun mi ati oluranlọwọ́ mi

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, jẹ ki sakramenti ti a ti gbà, ki o wẹ̀ wa nù, ki o sì mà dàbobo wa nipa agbara òre-ọfẹ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KARUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, gbọ́ ohùn mi ti mo fi kigbe pè ọ ; jẹ oluranlọwọ́ mi ; máṣe fi mi silẹ, bẹ̀ni ki o máṣe gàn mi, Ọlọrun Olugbala mi. *Ps.* Oluwa ni imọlẹ ati igbalà mi, tali emi o bẹ̀ru ? Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o ti pèse irú ohun rere ti oju

enia kò lè ri silẹ fun awọn ti o fẹ Ọ, tú irú imọ ifẹ rẹ sinu ọkàn wa, pe, nipa ìfẹ ọ ni ohun gbogbo ati jù ohun gbogbo lọ, ki awa ki o lè ri ileri rẹ gbà, ti o ta gbogbo ifẹ wa yọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Pet. 3).

Ẹnyin aya mi, ẹ jẹ ki isọkan pipé ki o mâ wà lârin gbogbo nyin, ki ẹ mâ ṣànu fun ara nyin, ẹ mâ fẹ ara nyin bi ará, ẹ ni iyọnu, ki ẹ sì mâ jẹ oniwa tùtu ati onirẹlẹ. Ẹ máṣe fi buburu san buburu, tabi èbú san èbú, ṣugbọn kàka bẹ ẹ mâ fi ibukún san, nitoripe eyiyí li a pè nyin si, ki ẹnyin ki o lè jogún ibukún. Nitori ẹniti o ba fẹ iye, ti o sì nfẹ ri ọjọ rere, ki o pa ahọn rẹ mọ kuro ninu buburu, ati ète rẹ ki o máṣe sọrọ ẹtan; ki o yà ara rẹ kuro ninu ibi, ki o sì mâ ṣe rere; jẹ ki o mâ wá alafia, ki o sì mâ lepa rẹ; nitori Oluwa tẹju rẹ mọ awọn olododo, etí rẹ sì ṣí si adua wọn; ṣugbọn oju Oluwa korò si awọn ti nṣe buburu. Tani yio sì lè ṣe nyin ni ibi, bi ẹnyin ba ní itara gbigbona fun ṣiṣe kiki ohun rere nikan; ṣugbọn bi ẹnyin ba jiyà nitori ododo, alabukúnfun li ẹnyin. Ẹ máṣe bẹru ibi ti nwọn nfẹ fi dẹruba nyin, ki ẹ má sì ṣe wà li aifaiyabalẹ, ṣugbọn ẹ ti ogo fun iwa mimọ ti Oluwa Jesu-Kristi li ọkàn nyin.

Graduali. Kiyesi i, Ọlọrun alâbo wa, ki o sì ṣijuwò awọn iranṣẹ rẹ. Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, gbọ́ adua awọn iranṣẹ rẹ, alleluia, alleluia. Ọba yio mâ yọ li agbara rẹ, Oluwa, yio sì yọ gidigidi nitori iranlọwọ rẹ. Alleluia.

Ihin rere (Mat. v, 20).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : Bikoṣe pe ododo nyin ba rekọja jù ti awọn akọwe ati awọn Farisi lọ, ẹnyin kì yio lè wọ inu ijọba ọrun bi o ti wù ki o ri. Ẹnyin ti gbọ bi a ti wí fun awọn ará igbâni pe : Iwọ kò gbọdọ pania ; ẹnikẹni ti o ba sì pania, yio wà li ewu idajọ. Ṣugbọn emi wí fun nyin pe, ẹnikẹni ti o ba binu si arakonri rẹ, yio wà li ewu idajọ ; ati ẹnikẹni ti o ba wí fun arakonri rẹ pe, Raka, yio wà li ewu ajọ-igbimọ ; ati ẹnikẹni ti o ba wí fun u pe, Iwọ aṣiwère, yio jẹbi iná ọrun apâdi. Nitorinâ bi iwọ ba nmu ẹbun rẹ wá siwaju altari, ti iwọ ba sì ranti pe, arakonri rẹ li ohun kan ninu si ọ, fi ẹbun rẹ silẹ niwaju altari nibẹ, ki o sì tète pada lọ lati ba arakonri rẹ làja nâ, nigbanâ ni ki o wá ru ẹbun rẹ.

Ifitọrẹ. Emi o ti ibukún fun Oluwa, ẹniti o fun mi ni oyé ; mo fi Ọlọrun siwaju mi nigbagbogbo, nitoriti o wà li ọwọ ọtún mi, ki a máṣe lè yí mi nipo pada.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki ẹbẹ wa ki o tũ Ọ ninu, ki iwọ ki o sì tẹwọgbà ẹbọ ti awọn ọmọ-ọdọ rẹ t'ọkọnri t'obirin, pe, ohunkohun ti olukuluku wọn ba ti rù lẹbọ si ogo orukọ rẹ, ki o lè sanfani fun igbalà gbogbo wọn ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ohun kan li emi ntọrọ lodọ Oluwa, on nâ li emi o mâ wá kiri, ki emi ki o lè mâ gbé inu ile Oluwa ni gbogbo ọjọ aiye mi,

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, tifunni, ki a lè wẹ awa ti iwọ fi ẹbun ọrun bọ nù kuro ninu ẹṣẹ ikọkọ wa, ki a si lè gbà wa kuro ninu ikẹkùn èṣu; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸFA LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa li agbara awọn enia rẹ, ati alâbo igbalà Kristi rẹ, tabi Ẹni-ita orórosi rẹ: Gbà awọn enia rẹ là, Oluwa, ki o si bukún fun ilẹ ini rẹ, ki o mâ ṣe akoso wọn lailai. *Ps.* Oluwa, iwọ li emi o kigbe pè; Ọlọrun mi, máṣe dakẹ si mi, nitori bi iwọ ba dakẹ si mi, emi o dabi awọn ti o sọkalẹ lọ sinu isà-okú. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun awọn ọmọ-ọgun, Iwọ ti iṣe ọlọrisun ati olufunni li ohun rere gbogbo, gbìn ifẹ orukọ rẹ si wa li ọkàn, ki o si mu ifọkànsìn ki o mâ bí si i ninu wa; ki iwọ ki o lè bọ ohun ti iṣe rere ninu wa, ati nipa itara gbigbona ti ifọkànsìn wa ki iwọ ki o si lè mâ pa eyi nâ ti iwọ ti bọ mọ ninu wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. VI, 3).

Ẹnyin ará mi, ẹnyin kò ha mọ pe gbogbo wa ti a ti batisi ninu Kristi Jesu, a batisi wa ninu *afarawé* ikú rẹ? Nitori a ti fi ibatisi sìn wa pọ pẹlu rẹ lati kú, pe gẹgẹ bi Kristi ti jinde kuro ninu okú nipa ogo Baba, bẹ gẹgẹ ni ki awa ki o mã rìn li ìwa titun. Nitori bi o basepe a ti gbìn wa pọ pẹlu rẹ ninu afarawé ikú rẹ, awa o ri bẹ pẹlu ninu ti ajinde rẹ. Bi a ti mọ pe a ti kàn ogbologbo enia wa mọ agbelebu pẹlu rẹ, ki a lè pa ara ẹṣẹ run, ati lati isisiyi lọ ki awa má sì se jẹ ẹrú ẹṣẹ mọ. Nitori ẹniti o kú, o bọ lọwọ ẹṣẹ. Nje bi awa ba ti bá Kristi kú, awa gbagbọ pe awa o sì wà làye pẹlu rẹ; nitori a mọ pe, bi Kristi ti jinde kuro ninu okú, kò ni ikú mọ, ikú kì yio sì lè jọba lori rẹ mọ. Nitori bi o ti kú, o kú fun ẹṣẹ lẹkanṣoṣo, bi o sì ti wà làye nisisiyi, o wà làye fun Ọlọrun. Bẹ gẹgẹ ni ki ẹ kà ara nyin si bi okú nitõtọ si ẹṣẹ, ati bi ẹniti o wà làye fun Ọlọrun nikanṣoṣo ninu Jesu-Kristi Oluwa wa.

Graduali. Oluwa, yípada diẹ si wa; rọju nitori awọn ọmọ-ọdọ rẹ. Oluwa, iwọ li o ti nṣe ibi asálà wa lati irandiran. Alleluia, alleluia. Oluwa, iwọ ni mo gbẹkẹle, lai mãṣe jẹ ki oju ki o tì mi; gbà mi ninu ododo rẹ, ki o sì dá mi silẹ. Dẹ etí rẹ silẹ si mi, ki o sì yara lati gbà mi. Alleluia.

Ihin rere (Mark 8).

Li ọjọ wọnyi bi ijọ enia ti pọ gidigidi, ti

nwọn kò sì ti lì onjẹ, Jesu pè awọn ọmọ-ẹhin rẹ jọ, o sì wí fun wọn pe : Ânu ijọ enia nṣe mi, nitoriti o di ijó mẹta nisisiyi ti nwọn ti wà lọdọ mi, nwọn kò sì lì ohun ti nwọn o jẹ : Bi emi ba sì ran wọn lọ si ile wọn laijẹun, nwọn yio dakú li ọna, nitori ọpọlọpọ ninu wọn ti òkere wá. Awọn ọmọ-ẹhin rẹ sì da a lohùn wí pe : Nibo li ao gbé ti lè fi akara tẹ awọn enia yi lọrùn li aginjù yi? O sì bi wọn lẽre wí pe : Iṣù akara melo li ẹnyin ní? Nwọn sì wí pe : Meje. O sì paṣẹ fun awọn enia lati joko ni ilẹ ; O sì mu iṣù akara meje nâ, o dupẹ, o bù wọn, o sì ti wọn fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ lati pín wọn, nwọn sì gbé wọn kalẹ niwaju awọn enia. Nwọn sì li ẹja kekere diẹ, o sure si i, o sì paṣẹ ki a gbé wọn kalẹ niwaju wọn pẹlu. Bẹni nwọn jẹ, nwọn sì yó nwọn sì kó agbọn meje ti o kún fun ajẹkùn ti o kù lọ. Awọn ti o jẹ ẹ to ìwọn ẹgbâji enia, O sì ran wọn lọ.

Ifitọrẹ. Fi ẹsẹ mi mulẹ ninu ipa ọna rẹ, Oluwa, ki emi ki o máṣe yẹ. Dẹ etí rẹ silẹ si mi, ki o sì gbọ́ ọrọ mi. Fi ânu rẹ ti o kún fun iyanu hàn, iwọ ti o gbà awọn ti o gbẹkẹle ọ là.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki ẹbẹ wa tù O loju, ati lojurere ânu rẹ ki o sì tẹwọgbà ẹbọ awọn enia rẹ ; ati pe ki ẹbẹ ati adua wa ki o máṣe jẹ asán, fifun wa, ki awa ki o lè ri gbà dajudaju eyiti awa nfi igbagbọ́ bère lọdọ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin

Komunioni. Emi o yí altari Oluwa ká, emi

o sì rù ẹbọ pẹlu ihó ayọ̀ ni ile mimọ́ rẹ̀; emi o sì kọ orin mimọ́ si Oluwa.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, bi a ti fi awọn ẹbun rẹ bọ́ wa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki a lè wẹ̀ wa mọ́ nipa agbara wọn, ki a sì lè dàbobo wa nipa iranlọwọ́ wọn; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KEJE LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹsẹ ti Misa. Ẹnyin gbogbo enia, ẹ ṣapẹ, ki ẹ sì fi ohùn ayọ̀ hó ihó iṣẹgun si Ọlọrun. *Ps.* Nitori Oluwa li Ọga-ogo, Ọlọrun ti o lẹ́ru, ati ọba nla lori ilẹ-aiye ghogbo. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun, ẹniti ipèse rẹ kì iṣìna ninu ohun ti o ṣe ilàna, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ lati mu ohun gbogbo ti o lè ṣe wa ni ibi kuro lọdọ wa, ki o sì fun wa li ohun gbogbo wọnyi ti o ṣe anfani fun wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. VI, 19).

Ẹnyin ará mi, emi nsọ̀rọ bi enia nitori ailera ara nyin. Nitori bi ẹnyin ti lò èya ara nyin ni sisìn ìwa aimọ́ ati aiṣedede lati dẹṣẹ, bẹ̀ni nisisiyi ki ẹnyin ki o sì lò èya ara nyin ni

sisìn ododo si ìwa mimọ́ nyin. Nitori nigbati ẹnyin nṣe ẹrú ẹ̀ṣẹ́, ẹnyin ti bọ́ lọwọ́ ododo. Nje eso kili ẹnyin ni nigbanâ ninu ìwakuwa ti oju ntì nyin si nisisiyi? Nitori ikú li opin nkan wọnyi. Ṣugbọn nisisiyi ti ẹnyin ti bọ́ lọwọ́ ẹ̀ṣẹ́, ti ẹnyin sì di ẹrú Ọlọrun, ìwa mimọ́ li eso ti ẹnyin ni ninu rẹ̀, ìye ti kò nipẹkun ni yio sì jẹ opin rẹ̀. Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ́. Ṣugbọn ôreọfẹ Ọlọrun li ìye ti kò nipẹkun ninu Jesu-Kristi Oluwa wa.

Graduali. Ẹ wá, ẹnyin ọmọde, ẹ fetisi mi, emi o kọ́ nyin li ibẹ̀ru Oluwa. Ẹ sunmọ́ ọdọ rẹ̀, ao tàn imọlẹ si nyin, oju kì yio sì tì nyin. Alleluia, alleluia. Ẹnyin gbogbo enia, ẹ ṣapẹ, ki ẹ sì fi ohùn ayọ̀ hó ihó iṣẹ́ gùn si Ọlọrun. Alleluia.

Ihin rere (Mat. VII, 15).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe: Ẹ kiyesara nyin nitori awọn eké woli ti o ntọ́ nyin wá ni wiwọ̀ aṣọ l'awọ agutan, ṣugbọn ninu, nwọn jẹ apanijẹ ikorikò. Eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn. A ha lè ká eso ajara lori ẹgún ọgán, tabi eso ọpọtọ́ ninu ẹ̀wọn bi? Bẹ̀ gẹgẹ ni gbogbo igi rere nseso rere, ṣugbọn igi buburu ni nseso buburu. Igi rere kò lè seso buburu, bẹ̀ni igi buburu kò lè seso rere. Gbogbo igi ti kò ba seso rere li a ke lùlẹ, a sì gbé e sọ sinu iná. Nitorinâ eso wọn li ẹnyin yio fi mọ̀ wọn. Kì iṣe gbogbo ẹniti nwí fun mi pe: Oluwa, Oluwa, ni yio wọ̀ inu ijọba ọrun, bikoṣe ẹniti nṣe ifẹ́ Baba mi ti mbẹ̀ li ọrun, ni yio wọ̀ inu ijọba ọrun.

Ifitọrẹ. Oluwa, gẹgẹ bi ninu irú ẹbọ sisun ti àgbo ati akọ-malu, ati gẹgẹ bi ninu ti ẹgbẹrun ọdọ-agutan ti o sanra, bẹ gẹgẹ ni ki o jẹ ki ẹbọ wa ri niwaju rẹ loni, ki o lè jẹ atẹwọgbà fun Ọ, nitori oju kì itì awọn ti ngbẹkẹle ọ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Olọrun, Iwọ ti o ti ṣe ikójọpọ awọn onirùru ẹbọ ti Majẹmu lailai di ẹbọ pipé kanṣoṣo, tẹwọgbà ẹbọ kannâ yi lọwọ awọn iranṣẹ rẹ ti o ti yà ara wọn sọtọ fun ọ, ki o sì sọ ọ di mimọ nipa ibukún nâ ti iwọ ti fi sọ ẹbọ Abẹli di mimọ, ki ohunkohun ti olukuluku wa ba ti rù lẹbọ si ogo Olá nla rẹ ki o lè ṣe anfani fun gbogbo wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Dẹ etí rẹ silẹ si adua mi, Olọrun, ki o sì yara lati gbà mi là.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki ânu rẹ ki o gbà wa kuro ninu ìwa buburu wa nipa agbara imularada ti sakramenti yi. ki o sì mu wa lọ siwaju si i ninu ododo ati ìwa rere; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸJỌ LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ tì Misa. Olọrun, awa ti ri ânu rẹ

gbà lârin tempeli rẹ. Gẹgẹ bi orukọ rẹ, bẹni iyìn rẹ tânka titide opin ilẹ aiye ; ọwọ́ ọtún rẹ sì kún fun ododo. *Ps.* Ẹni-nla ni Oluwa, o sì yẹ fun iyìn ailopin ni ilú Ọlọrun wa ati li òke mimọ́ rẹ̀. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, nipa ânu rẹ fun wa li ẹmí lati mâ ni iro rere, ati lati mâ ṣe irú ohun wọnyi ti o tọ́ nigbagbogbo, ki awa ti kò lè wà lâye laisi rẹ, ki a lè mâ hùwa gẹgẹ bi ifẹ́ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Rom. VIII, 12.).

Ará mi, awa kì iṣe ajigbese ti ara, ti ao fi wà nipa ti ara. Nitori bi ẹnyin ba wà nipa ti ara, ẹnyin o kú ; ṣugbọn bi ẹnyin ba fi ẹ̀mí pọn iṣẹ ti ara loju, ẹnyin o yè. Nitori gbogbo awọn ẹniti Ẹmi Ọlọrun ba nṣe amọ̀na fun, awọn ni iṣe ọmọ Ọlọrun. Nitori ẹnyin kò gbà ẹmí ẹrú, ti o tún da nyin duro ninu ibẹ̀ru, ṣugbọn ẹnyin ti gbà Ẹmi isọdọmọ, nipa eyiti awa fi nkepè Abba (Baba). Nitori ẹmi tikalarẹ̀ li o njẹ́ ẹmi wa li ẹrí pe, ọmọ Ọlọrun li awa nṣe. Bi awa ba ṣe ọmọ, ajogún ni wa pẹlu, ani ajogún Ọlọrun, ati ajumọjogún pẹlu Kristi.

Graduali Ọlọrun mi, mâ jẹ âbo ati ibi asálà mi lati gbà mi là. Ọlọrun, iwọ ni mo gbẹ́kẹle : Oluwa, lai máṣe jẹ ki oju ki o tì mi. Alleluia, alleluia. Oluwa li ẹni-nla, o sì yẹ fun iyìn ailopin ni ilú Ọlọrun wa ati ni òke mimọ́ rẹ̀. Alleluia.

Ihin rere (Luk. xvi, 1).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ọkọnri ọlọrọ̀ kan ti wà, ti o ni ọmọloju kan ; on nâ ni nwọn fi sûn u pe, o nfi ohun iní rẹ̀ ṣòfo. O pè e wá. o sì wí fun pe : Kini mo gbọ́ nipa tirẹ? Ṣiro iṣẹ rẹ bi ọmọloju, nitori kì yio lè ṣe itọju ohun iní mi pẹ́ mọ́. Nigbanâ ni ọmọloju nâ wí ninu ara rẹ̀ pe : Ewo li emi o ṣe? Nitori oluwa mi gbà iṣẹ itọju ohun iní rẹ̀ lọwọ́ mi : Emi kò lè wàlẹ, oju sì ntì mi lati ṣagbe. Mo mọ̀ bi emi o ti ṣe, nigbati a ba mu mi kuro nibi iṣẹ mi, ki nwọn ki i o lè gbà mi sinu ile wọn. Nitorinâ o pè olukuluku awọn ajigbese oluwa rẹ̀ sọdọ rẹ̀, o sì wí fun ekini pe : Elo ni iwọ jẹ oluwa mi? Eyini dahûn wipe : Ọgọrun agbá òróro. O sì wí fun u pe : Gbà iwe rẹ, ki iwọ sì joko nisisiyi, ki o sì kọ adọta. Lẹhin eyi o wí fun ẹnikeji pe : Elo ni iwọ jẹ? Eyini sì wipe : Ọgọrun òṣuwọn alikama. O sì wí fun u pe : Gbà iwe rẹ, ki o sì kọ ọgọrin. Oluwa ti ọmọloju alaiṣõtọ nâ sì yìn i, nitoriti o fi ọgbọ́n ṣe e, nitori awọn ọmọ aiye yi gbọ́n li ọ̀na iṣẹ wọn jù awọn ọmọ imọlẹ lọ. Bẹ̀ gẹgẹ ni mo wí fun nyin, ẹ fi ọrọ̀ aiṣõtọ ṣe ọrẹ́ fun ara nyin, pe nigbati o ba tán fun nyin, ki nwọn ki o lè gbà nyin sinu ibugbé aiyeraiye.

Ifitọrẹ Oluwa, iwọ o gbà awọn onirẹlẹ ọkàn là, iwọ o sì rẹ̀ awọn onigberaga silẹ : nitoripe tani iṣe Ọlọrun, bikoṣe iwọ, Oluwa?

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fi ojurere gbà

ẹbun ti a ru lẹbọ si Ọ bi ôre rẹ, ki ohun ijinlẹ mimọ yi, nipa iṣẹ agbara ôre-ọfẹ rẹ ki o lè sọ wa di mimọ niwọn ọjọ aiye wa, nikẹhin ki o sì lè mu wa de ibi alafia ainipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹ tọ ọ wò, ki ẹ sì ri bi Oluwa ti ṣe oninu rere to; alabukún fun li ẹniti o gbẹkẹle E.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki sakramenti mimọ yi ki o tún ọkàn ati ara wa ṣe, ki awa ki o lè mọ agbara ohun ti a mbọlafun ninu ẹbọ yi; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸSAN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Kiyesi i, Ọlọrun li oluràn-lọwọ mi, Oluwa sì li alàbo ẹmi mi. Yí ibi ti awọn ọtá mi nlẹ ṣe si mi pada sori wọn, ki o pa wọn run ninu otitọ rẹ. *Ps.* Ọlọrun, gbà mi là nipa agbara rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, jẹ ki etí ânu rẹ ki o ṣí silẹ si adua awọn ẹniti mbẹbẹ lọdọ rẹ, atipe ki iwọ ki o lè fun wọn li ohun ti nwọn mbère, mu wọn bère irú ohun ti yio mà wù Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Kor. 10).

Ará, ọ jẹ ki awa ki o máṣe ṣe ifẹkufẹ si ohun buburu, gẹgẹ bi awọn ará Israeli ti ṣe ifẹkufẹ, Bẹ̀ni ki ẹnyin ki o má sì ṣe abọrisa, bi awọn miran ninu wọn, gẹgẹ bi a ti kọ ọ si iwe pe : Awọn enia nâ joko lati mâ jẹ, ati lati mâ mu, nwọn si dide lati mâ ṣe ariya. Bẹ̀ni ki awa ki o má sì ṣe àgbere, bi awọn miran ninu wọn ti ṣe àgbere, nitori eyiti ẹgbâ mọkanla lelẹgbẹrun enia kú ni ijọ kan ninu wọn Bẹ̀ni ki awa ki o máṣe dan Kristi wò, gẹgẹ bi awọn ẹlomiran ninu wọn ti dan a wò, ti a sì fi ejò pa wọn run. Bẹ̀ni ki ẹnyin ki o máṣe kùn ninu nyin, gẹgẹbi awọn ẹlomiran ninu wọn ti kùn, a sì pa wọn run lati ọwọ oluparun ni wá. Gbogbo nkan wọnyi ti o de si wọn sì jasi apẹrẹ fun wa, a sì kọ wọn si iwe lati jẹ ikilọ fun awa ti o de igbẹhin aiye. Nitorinâ ẹnikẹni ti o ba rò pe on duro, ki o kiyesara ki o mába ṣubu. Ẹ máṣe jẹ ki idanwò ki o bá nyin, bikoṣe irú eyiti o mọ nibá fun enia Olododo li Ọlọrun ; on kì yio sì jẹ ki a dan nyin wò jù agbara nyin lọ, ṣugbọn yio ṣọ idanwò nâ di anfani fun nyin, ki ẹnyin ki o lè gbà a.

Graduali. Ọlọrun Oluwa wa, bawo ni orukọ rẹ ti ni iyìn to ni gbogbo aiye ! Nitori ogo rẹ mọlẹ loju ọrun. Alleluia, alleluia. Ọlọrun mi, gbà mi lọwọ awọn ọtá mi, ki o sì dâbobo mi kuro lọwọ awọn ti o dide si mi. Alleluia.

Ihin rere (Luk. xix, 41.)

Nigbati Jesu sunmọ tosi Jerusalemu, ti o sì

ṣijuwò ilú nâ, o ṣokún si i lori, o nwipe : Ibaṣe pe li ojó oni yi a tún fifun ọ, iwọ nà mọ ohun ti o lè mu alafia wá fun ọ! Ṣugbọn nisisiyi nwọn pamọ kuro loju rẹ. Nitori ojó mbò fun ọ, ti awọn ọtá rẹ yio wà yàra yí ọ ká, nwọn o si sé ọ mó, nwọn o si há ọ mó niha gbogbo, nwọn o si wó ọ lulẹ, ati awọn ọmọ rẹ ti o wà ninu rẹ, nwọn kì yio si fi okuta kan silẹ lori okuta ninu rẹ, nitoriti iwọ kò mọ akòko ibẹwo rẹ. O si wọ inu tempeli lọ, o si bẹrẹsi ilé awọn ti ntà ati awọn ti nrà ninu rẹ sode, o wí fun wọn pe : A kó ọ si iwe pe : Ile adura ni ile mi, ṣugbọn enyin ti ṣọ ọ di ihò olè. O si nkóni lojojumọ ni ile Ọlọrun.

Ifitọrẹ. Otitọ li ofin Ọlọrun ; o nmu ọkàn yọ ; idajọ rẹ si dùn jù oyin ati afara oyin lọ ; nitorinâ ni iranṣẹ rẹ ṣe pa wọn mọ bi o ti yẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fun wa li ôreọfẹ lati sunmọ sakramenti mimọ yi nigbakúgba, ati lati gbà a bi o ti yẹ, nigbati o jẹ pe nigbakúgba ti a ṣe iranti ẹbọ rẹ, a tún iṣẹ irapada wa ṣe ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹnikẹni ti o ba jẹ ara mi, ti o ba si mu ẹjẹ mi, o ngbé inu mi, emi si ngbé inu rẹ, Oluwa wí.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki sakramenti

rẹ ti a ti gbà ki o wè wa mó, ki o sì da wa pọmọ Ọ titi; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸWA LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹsẹ ti Misa. Nigbati emi kigbe pè Oluwa, on gbohùn mi, o sì gbà mi lọwọ awọn ọtá mi: Ẹniti o wà ṣaju aiye gbogbo, ti yio sì wà titilai ti rè won silẹ. Fi âjo rẹ fun Oluwa, on yio sì bó ọ. *Ps.* Ọlọrun, fetisi adura mi, má sì ṣe gàn ibère mi; fiyesi mi, ki o sì da mi lohùn. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o fi agbara rẹ hàn nipataki ni didariji ni ati ni ṣiṣe ânu, dà iṣura ânu rẹ ni si wa lori lọpòlọpò, ki awa ki o lè mà sure lẹhin ohun ini ọrun ti iwọ ti ṣe ileri, fun wa, ki a sì so wa dì alabapin ninu iṣura rẹ ọrun.

Epistoli (1 Cor. 12).

Ará, ẹnyin mọ pe, nigbati ẹnyin ti jẹ keferi, ẹnyin ti jẹ ki a fà nyin lọ sodọ awọn odi orisa, gègè bi a ti dari nyin. Nitorinâ mo wí fun nyin pe kòsi ẹnikan, ti nsòrọ nipa Ẹmi Ọlọrun, ti ifi Jesu bú, ati pe kòsi ẹniti o lè wí pe: Oluwa ni Jesu ṣe, bikose nipa Ẹmi-Mimọ. Nitôto onirùru ôre-ọfẹ li o wà, ṣugbọn Ẹmi kannâ ni; ati onirùru iṣẹ iranṣẹ li o sì wà, ṣugbọn Oluwa kannâ ni; ati onirùru ôre-ọfẹ

iṣiṣẹ li o si wà, ṣugbọn Ọlọrun kannâ ni nṣiṣẹ ohun gbogbo ninu gbogbo enia. Ṣugbọn awọn ẹbun Ẹmi-Mimọ ti o nfarahàn lode wọnyi li a nfi fun olukuluku enia nitori anfani gbogbo enia ninu Eklesia. Enikan ri ẹbun isọrọ pẹlu ọgbọ́n gbà lọwọ́ Ẹmi-Mimọ́; ẹlomiran ri ẹbun isọrọ pẹlu imọ gbà lọwọ́ Ẹmi kannâ; ẹlomiran ri ẹbun igbagbọ́ gbà lọwọ́ Ẹmi kannâ; ẹlomiran ri ẹbun imunilarada gbà lọwọ́ Ẹmi kannâ; ẹlomiran ri ẹbun iṣe iṣẹ iyanu gbà; ẹlomiran ri ẹbun isọtẹlẹ gbà; ẹlomiran ri ẹbun ìmọ inu ọkàn enia gbà; ẹlomiran ri ẹbun ifọ̀ onirũru ède gbà; ẹlomiran ri ẹbun itumọ̀ ède gbà. Ṣugbọn gbogbo ẹbun wọnyi li Ẹmí kan ati ọkannâ nṣiṣẹ, o npín wọn fun olukuluku enia gẹgẹ bi o ti wù U.

Graduali. Oluwa, pa mi mọ́ bi ọmọ-oju; ràdọbò mi labẹ ojiji iyẹ́ apa rẹ; jẹ ki idajọ mi ki o mâ ti imọlẹ oju rẹ jáde wá; jẹ ki oju rẹ ki o mâ wò ohun ti o ṣe dède. Alleluia, alleluia. Oluwa, ki a kọrin iyìn si ọ ni Sioni, ki a sì san ileri-ifẹ́ fun ọ ni Jerusalemu, ni isìn ti o yẹ fun ọ. Alleluia.

Ihin-rere (Luk. xviii, 9).

Nigbanâ ni Jesu pa owe yi fun awọn kan, ti nwọn gbẹkẹle ara wọn bi ẹnipe awọn li ododo, ti nwọn sì ngàn awọn ẹlomiran pe: Awọn ọkọnri meji lọ si ile Ọlọrun lati gbadua; ọkan amâ ṣe Farisi (ẹni agabagebe), ati ekeji agbowode. Eyi Farisi sì dide, o sì ngbadua ninu ara rẹ̀ wí bayi pe: Ọlọrun, mo dupẹ lọwọ́

rẹ, nitoriti emi kò ri bi awọn enia iyokù, ti iṣe olè, alaiṣòtọ, panṣaga, ani pẹlu bi agbowode yi. Emi ngbàwẹ làrin meji li ọsẹ; mo sì san idamẹwa ohun gbogbo ti mo ni. Ṣugbọn agbowode duro li òkere, kò tilẹ jẹ gbé oju rẹ soke ọrun, o sì lù ara rẹ li ôkan-àiya, o sì wi pe: Ọlọrun, ṣânu fun mi ẹlẹṣẹ. Mo wi fun nyin pe, ọkọnri yi sọkalẹ lọ si ile rẹ ni idalare jù ekeji lọ: nitori ẹnikẹni ti o ba gbé ara rẹ ga on li ao rẹ silẹ, ẹniti o ba sì rẹ ara rẹ silẹ on li ao gbé ga.

Ifitọrẹ. Oluwa, iwọ ni mo gbé ọkàn mi soke si Ọlọrun mi, iwọ ni mo gbẹkẹle; máṣe jẹ ki oju ki o tì mi, bẹni ki o má sì ṣe jẹ ki awọn ọtá mi rẹrin mi, nitori oju kì yio ti ẹnikẹni ti o duro tì ọ.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, fi ojurere gbà ẹbọ ti a yà sọtọ fun ọ, ti iwọ sì fifun wa lati ru si ogo orukọ rẹ, ki o lè ṣe iranlọwọ igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa, iwọ o tẹwọgbà ẹbọ ododo, ẹbọ sisun ati ẹbun ti a ru lori altari rẹ

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa Ọlọrun wa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki iwọ ki o máṣe kọ iranlọwọ rẹ fun awọn ẹniti iwọ kò dawọduro lati mâ fi sakramenti mimọ rẹ bọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KỌKANLA LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ọlọrun ti mbẹ ni Ibi mimọ rẹ, Ọlọrun ti o mu awọn enia oninukan gbé inu ile kanna, yio ti ilera ati agbara fun awọn enia rẹ. *Ps.* Ki Ọlọrun ki o dide, ki o si tú awọn ọtá rẹ ká; ki gbogbo awọn ti o korira rẹ ki o sálọ kuro niwaju rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o rekọja itoye ati ifé awọn eniti mbẹbẹ lodọ rẹ nipa ọpọ inu rere; tú ànu rẹ si wa lori; mà dari ohun wọnyi ji wa ti ọkàn wa mbẹru, ki o si mâ fun wa li ohun rere wọnyi ti adura wa kò dalaṣà lati bère; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (1 Kor. 15).

Ará, emi nran nyin leti Ihin rere nâ ti mo ti wàsu fun nyin, ti ẹnyin si ti gbà, ninu eyiti ẹnyin si duro ṣinṣin, nipasẹ eyiti ao si ti gbà nyin là, bi ẹnyin ba pa a mọ gẹgẹ bi mo ti wàsu rẹ fun nyin, bikoṣe pe ẹnyin ba gbagbọ lasan. Nitoripe ṣiwaju ohun gbogbo, mo ti fun nyin, mo si ti kọ nyin li eyiti emi pàpa ti gbà, pe: Kristi ti kú nitori èṣẹ wa, gẹgẹ bi Iwe mimọ ti wí; atipe a sinkú rẹ, atipe o tún jinde ni ijọ kẹta, gẹgẹ bi Iwe mimọ ti wí; atipe o farahàn Kefa, lẹhin eyini o farahàn awọn me-

jejila. Lẹhin eyini o farahàn awọn arákọnri ti o jù ẹdẹgbẹta lọ lẹkanṣoṣo, ọpọ awọn ẹniti o wà titi ti di isisiyi, ṣugbọn diẹ ninu wọn ti kú. Lẹhin eyini o farahàn Jakọbu, lẹhinnà o farahàn gbogbo awọn Apostoli; ati nikẹhin, lẹhin gbogbo wọnyi o farahàn mi pẹlu, ẹniti iṣe ọmọ alaipé akokò rẹ. Nitori emi li ẹni-ikẹhin ninu awọn apostoli, ti emi kò sì yẹ lati pè ni apostoli, nitori mo ti ṣe inunibini si ijọ-enia Ọlọrun. Ṣugbọn nipa ôre-ọfẹ Ọlọrun mo ri bi mo ti ri, ôre-ọfẹ rẹ kò si je asan ninu mi.

Graduali. Ọlọrun li aiya mi gbẹkẹle, a si ràn mi lọwọ; ara mi si ti gbà agbara titun, emi o si mâ yìn Ọlọrun tọkàntọkàn. Oluwa, iwọ li emi kigbe pè; Ọlọrun mi, máṣe dakẹ si mi, bẹni ki o má si ṣe lọ kuro lọdọ mi. Alleluia, alleluia. E kọrin soke si Ọlọrun, oluranlọwọ wa; ẹ hó ihó ayọ si Ọlọrun Jakọbu, ki ẹ si kọrin didùn si I pẹlu dùru. Alleluia.

Ihin rere (Mark VII. 31).

Nigbanâ ni Jesu lọ kuro li àgbegbe Tire on Sidoni, o si wá si okun Galili lârin àgbegbe Ilúmẹwa (Dekapoli). Nwọn si mu enia kan wá sọdọ rẹ ti etí rẹ di, ti o si yadi li ahọn rẹ, nwọn si bẹ ẹ pe, ki o gbé ọwọ rẹ le e. Jesu si mu u kuro lârin ijọ enia lọ sapakan, o si fi ikà rẹ si i l'etí, nigbati o tutọ, o si fi ọwọ tọ ọ li ahọn, o si gbé oju soke ọrun, o kẹdùn, o si wí fun u pe; Efeta, eyiyi ni, iwọ ṣí silẹ. Lojukannà etí rẹ ṣí, okùn ahọn rẹ si tú, o si nsọrọ daradara. O si kilọ fun wọn pe, ki nwọn ki o

máṣe sọ fun ẹnikẹni ; ṣugbọn bi o ti nkilọ fun wọn to, bẹ̀gẹgẹ ni nwọn sì nrohìn rẹ̀ kakiri to, ẹnu sì yà wọn gidigidi rekọja, nwọn wipe : O ṣe ohun gbogbo dara ; o mu ki aditi gbọran, ki odi sì ṣohùn.

Ifitọrẹ. Oluwa, iwọ li emi o yìn logo, nitori iwọ li o ràn mi lọwọ́, ti iwọ kò sì jẹ ki awọn ọtá mi ki o yọ̀ mi ; Oluwa Ọlọrun mi. mo ti kigbe pè ọ, iwọ sì ti mu mi larada.

Adura ti a kà jejẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fi ojurere wò awọn iranṣẹ rẹ, ki ẹ̀bun ti a ru lẹbọ si Ọ ki o lè jẹ atẹwọgbà fun Ọ, ki o sì mâ ti wa lẹhin ninu ailera wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Fi ohun-ini rẹ bọwọ fun Ọlọrun, ki o sì fun u li akọso ninu gbogbo eso rẹ, bẹ̀ni abà rẹ o kún fun ọ̀pọ agbado ati agbá rẹ yio sì kún fun ọti vini titún.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, nipa gbigbà sakramenti mimọ́ rẹ, jẹ ki a lè ri iranlọwọ́ gbà fun ọkàn ati ara wa, pe nipa gbigbà imularada awọn mejeji, ki awa ki o lè ni alafia n'ijọ́ kan lati ri ẹkún ohun imularada ọrun yi gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KEJILA LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ọlọrun, wá gbà mi; Oluwa yara lati ràn mi lọwọ; ki oju ki o tì awọn ọtá mi ti nwá ifarapa mi, ki nwọn ki o sì dãmu, *Ps.* Jẹ ki nwọn ki o pada sẹhin, ki nwọn ki o sì dãmu, awọn ti nfẹ lati ṣe mi ni ibi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati alânu, Iwọ ti o fun awọn onigbagbọ rẹ li ôre-ọfẹ lati sìn Ọ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifun ni, ki awa ki o lè mâ sure laikọsẹ lẹhin ohun ini ọrun ti iwọ ti ṣe ileri fun wa; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa Amin.

Epistoli (2 Kor. III, 4).

Ará mi, nipa Kristi li awa ni irú igbẹkẹle sodọ Ọlọrun, kì iṣe pe awa to fun ara wa lati ni ìro rere kan bi ẹnipe nipa agbara awa tikalawa, ṣugbọn imọ wa ti ọdọ Ọlọrun wá; ẹniti o sì mu wa yẹ lati ṣe iranṣẹ Majẹmu titun, kì iṣe nipa ọrọ, bikoṣe nipa Ẹmí; nitori ọrọ amâ pani, ṣugbọn Ẹmí amâ sọnidi alâye. Bi iṣe iranṣẹ ti ọrọ ipani (ofin lailai) ti a fin sara okuta, ba jẹ ologo, tobẹ ti awọn ọmọ Israeli kò lè tejumọ oju Mose, nitori ogo oju rẹ, eyiti o di asan, bawo ni yio ha ti ri ti iṣẹ iranṣẹ ti Ẹmí ki yio lè jẹ ologo julọ? Nitori bi iṣẹ iranṣẹ ti idalẹbi ba jẹ ologo, melomelo ni iṣẹ iranṣẹ ti ododo yio rekọja rẹ logo.

Graduali. Emi o mà fi ibukún fun Oluwa nigbagbogbo; iyìn rẹ yio mâ wà li ẹnu mi titilai. Ọkàn mi yio mâ ṣogo lati yìn Oluwa; ki awọn ọlọkàn tùtu ki o gbọ, ki nwọn ki o sì yọ. Oluwa, Ọlọrun igbalà mi, emi nkigbe lôsan ati loru niwaju rẹ.

Ihin rere (Luk. x, 23).

Nigbanà ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe: Alabukún fun li oju ti nri ohun ti ẹnyin nri; nitori mo wí fun nyin pe, ọpọlọpọ woli ati ọba li o nfẹ lati ri ohun ti ẹnyin nri nwọn kò sì ri wọn, ati lati gbọ ohun ti ẹnyin ngbọ, nwọn kò sì gbọ wọn. Sì kiyesi i, amofin kan dide lati dán A wò, o sì wí pe: Olukọni, kili emi iba ṣe ki emi ki o lè jogún iye ainipẹkun? Jesu sì wí fun u pe. Kili a kọ sinu iwe ofin? bi iwọ ti kà a? Eyini sì dahùn wipe: Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, gbogbo ọkàn rẹ, gbogbo agbara rẹ ati gbogbo inu rẹ fẹ Oluwa Ọlọrun rẹ, ati ẹnikeji rẹ bi ara rẹ. Jesu sì wí fun u pe: Iwọ dahùn rere: ṣe eyi, iwọ o sì yè! Ṣugbọn on nfẹ lati da ara rẹ lare, o sì wí fun Jesu pe: Njẹ tani ẹnikeji mi? Jesu sì dahùn wipe: Ọkọnri kan nti Jerusalemu lọ si Jeriko, o sì bọ si ọwọ awọn olè; awọnyi bọ ọ lasọ, nwọn sá a lọgbẹ, nwọn si fi i silẹ lọ laipa a li apatán. O sì ṣe alufa kan nsokalẹ lọ li ọna kanna, o ri i, o sì bá tirẹ lọ. Lefiti kan sì de ibẹ nà pẹlu, o ri i, o sì rèkọja lọ. Ṣugbọn ará Samaria kan, ti nrè àjo, de itosi rẹ, o ri i, ânu sì ṣe e. O tọ ọ lọ, o dà oróro ati ọti vini si ọgbẹ rẹ, o di i, o sì gbé e lori ẹṣin rẹ, o sì mu

u wá si ile èro, o sì nṣe itoju rẹ̀. Ni ijọ́ keji o yọ kọpọ meji jade, o fifun bàle ile èro, o sì wí fun u pe : Mà toju rẹ̀, ohunkohun ti iwọ ba sì ná si i, emi o san a pada fun ọ, nigbati emi ba npada bọ̀. Ninu awọn meteta wọnyi tani iwọ ṣebi iṣe ẹnikeji ẹniti o bọ́ si ọwọ́ awọn olè? Amofin sì dahùn wipe : Ẹniti o ṣãnu fun u. Jesu sì wí fun u pe : Lọ, ki iwọ ki o sì ṣe bẹ̀ gẹgẹ.

Ifitorẹ. Mose gbadua yi niwaju Oluwa Olorun rẹ̀ wipe : Etiṣe ti iwọ fi binu si awọn enia rẹ̀? Rẹ̀ ibinu rẹ̀ silẹ̀ ; ranti Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu, ẹniti iwọ fi ibura ṣe ileri fun lati fun wọn li ilẹ̀ ti o ṣàn fun wara ati oyin. Ibinu Olorun sì tùtu, o sì yí ọkàn pada niti ibi nâ ti o ti sọ pe on o ṣe si awọn enia rẹ̀.

Adura ti a hà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, ti ojurere wò ẹbọ yi ti a ru si O lori altari mimọ́ rẹ̀, ki o lè fun wa li idariji ẹ̀ṣẹ̀ wa, ki o sì lè ti ogo fun orukọ rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Eso iṣẹ̀ ọwọ́ rẹ̀ li iwọ o fi bọ́ aiye, Oluwa, iwọ mà mu onjẹ jade lati ilẹ̀ wá, ati ọti vini ti imu ọkàn enia yọ̀, ati oróro ti idà ayọ́ si oju enia, ati onjẹ ti imu enia larale.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ̀, jẹ̀ ki sakramenti mimọ́ rẹ̀ ti awa ti gbà ki o lè sọ wa di alàye, ki o sì lè fun wa li idariji ẹ̀ṣẹ̀ wa, ati àbo ti a nṣe alaini ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸTALA LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, kiyesi majẹmu rẹ; máṣe gbagbe ọkàn awọn talakà rẹ lailai; dide, Oluwa, gbà ẹjọ ara rẹ rò, ki iwọ ki o sì gbọ́ adua awọn ẹniti nṣafẹri rẹ. *Ps.* Ọlọrun, êṣe ti iwọ fi ṣa wa tì? Êṣe ti ibinu rẹ fi ngbona si awọn agutan agbo rẹ? Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, mu igbagbọ́, ireti ati ifẹni pọ̀si i ninu wa; atipe ki awa ki o lè ri ohun ti iwọ ti ṣe ileri gbà, mu wa fẹ eyi ti iwọ pa laṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Gal III, 16).

Ará mi, awọn ileri Ọlọrun li a ti ṣe fun Abrahamu, ati fun irú-ọmọ rẹ. Iwe mimọ́ kò wí pe: Fun awọn irú-ọmọ rẹ, bi ẹnipe o sọ̀rọ ti ọ̀pọlọpọ, ṣugbọn bi ẹnipe o sọ̀rọ ti ọkàn: Fun irú-ọmọ rẹ eyiti iṣe Kristi. Eyi li emi nwipe: Majẹmu ti Ọlọrun ti fi idi rẹ mulẹ, ofin ti a fifunni li ọgbọ̀n le nirinwo ọdún lẹhin rẹ̀ kò lè sọ ọ dasan, bẹ̀ni kò sì lè pa ileri nâ run. Nitoripe bi ogún nâ ba ṣe nipa ofin, kì iṣe nipa ileri mọ́. Ṣugbọn nipa ileri li Ọlọrun ti fi i fun Abrahamu. Njẹ nitori kini a fun ni li ofin? A ti dá ofin silẹ nitori ẹ̀ṣẹ, titi irú-ọmọ ti a ti ṣe ileri fun yio fi de; A sì ti fi ofin nâ le onilàja kan lọwọ́ nipasẹ awọn Angẹli Ṣugbọn

onilàja kì iṣe ti ẹnikan, ọkan sì li Ọlọrun; Njẹ ofin ha lodi sì ileri Ọlọrun bi? Ki a má ri i. Nitori ibaṣepe a ti fun ni li ofin kan ti o lè fi ìye fun ni, nitôtọ ododo iba ti ipasẹ ofin wá. Ṣugbọn Iwe mimọ ti há ohun gbogbo mọ abẹ ẹṣẹ, ki a le fi awọn ileri nipa igbagbọ́ Jesu-Kristi fun awọn ti o gbagbọ́.

Graduali. Oluwa, kiyesi majẹmu rẹ; máṣe gbagbe ọkàn awọn talakà rẹ lailai. Oluwa, gbà ejọ ara rẹ rò, ki o sì ranti ẹgàn ti awọn iranṣẹ rẹ ti gbà. Alleluia, alleluia. Oluwa li o ti nṣe âbo wa lati irandiran. Alleluia.

Ihin rere (Luk. vxii, 11).

Nigbati Jesu nlọ si Jerusalemu, o kọja lârin Samaria ati Galili; bi o sì ti mwọ́ inu ileto kan lọ, o pade awọn ọkọnri adẹtẹ mẹwa, ti nwọn duro li òkere. Nwọn sì nahùn soke wí pe: Jesu, Oluwa wa, ṣànu fun wa. Nigbati o ri wọn, o wí fun wọn pe: Ẹ lọ, ẹ fi ara nyin hàn fun awọn saserdoti. O sì ṣe, bi nwọn ti nlọ, nwọn ri imularada. Nigbati ọkan ninu wọn ri pe a mu on larada, o pada ṣehin, o fi ohùn rara yìn Ọlọrun logo, o wólẹ lẹba ẹsẹ Jesu, o sì ndupẹ fun u. Eyini sì ni ará Samaria. Jesu sì dahùn wipe: Awọn mẹwa kì a ṣọ di mimọ? Awọn mẹsan iyokùn ha dà? A kò ri ẹnikan ti o pada wá lati fi ìyìn fun Ọlọrun, bikoṣe alejò yi. O sì wí fun u pe: Dide, mà lọ, igbagbọ́ rẹ ti gbà ọ là.

Ifitọrẹ. Oluwa, iwọ ni mo gbẹkẹle; mo ti wipe, iwọ li Ọlọrun mi, ìgba mi mbẹ li ọwọ́ rẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi ojurere wò awọn enia rẹ ati ẹbun wọn, pẹ, lẹhin igbati a ti tù Ọ ninu nipa ẹbọ yi, ki iwọ ki o lè dari ẹṣẹ wa jì wa, ki iwọ ki o sì lè fun wa li ohun ti a mbère ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa, iwọ ti fun wa li àkara ti o tọrun wá, ti o ni gbogbo adùn ninu rẹ, ti o sì dùn ni itọwò.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa ti o ti gbà sakramenti mimọ rẹ mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki a lè ri agbara titún gbà lati lọ siwaju li ọna igbalà ainipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸRINLA LẸHIN PENTEKOSTI.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Olorun, alàbo wa, kiyesi i, ki o sì ṣijuwò oju Ẹni-ita oróro si rẹ ; nitoripe ọjọ kan ti a nlò ni ile mimọ rẹ san jù egbẹrun ọjọ lọ nibo miran. *Ps.* Bawo ni Ibi mimọ rẹ ti lẹwà to, Oluwa awọn ọmọ-ogun ! Ohaha mu ọkàn mi, o sì fẹrẹ dakú fun ifẹ atiwọ inu agbalá Oluwa, Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, pa Eklesia rẹ

rẹ ká, yio sì gbà wọn là. Ẹ tọ ọ wò, ki ẹ sì ri bawo ni Ọlọrun ti jẹ oninurere to.

Adura ti a kà jejẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifun ni ki ẹbọ ti o gbàni là yi, ki o lè di ètutu fun ẹṣẹ wa, ki o sì lè ba wa làja pẹlu Ọlánla rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ṣiwaju ohun gbogbo ẹ tète mâ wá ijọba Ọlọrun, gbogbo ohun iyokù o li ao sì fi kún u fun nyin, ni Oluwa wí.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki sakramenti mimọ rẹ ki o lè mâ wẹ wa mọ, ki o sì mâ dâbobo wa nigbagbogbo, ki o sì mu wa lọ si ibi igbalà ainipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸDOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, dẹ etí rẹ silẹ si adua mi, ki o sì da mi lohùn ; Ọlọrun mi, gbà ọmọ-ọdọ rẹ ti o gbẹkẹle ọ, là : Ṣânu fun mi, Oluwa, nitoriti iwọ li emi nkigbe pè lojojumọ. *Ps.* Mu ọkàn iranṣẹ rẹ yọ, nitori iwọ ni emi gbé ọkàn mi soke si Ọlọrun mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, jẹ ki ânu rẹ ki o mâ wẹ̀ Eklesia rẹ mọ́, ki o sì mâ dàbobo o tililọ, atipe nitori kò lè duropẹ li alafia laisi rẹ, mâ ṣakoso rẹ̀ titilai nipa iranlọwọ́ ôre-ọfẹ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin

Epistoli (Galat. v, 25).

Ará mi, bi awa ba wà lâye nipa ti ẹmí, ẹ jẹ ki a sì mâ rìn nipa ti ẹmí. Ẹ máṣe jẹ ki a mâ ṣafẹri ogo asan, tobẹ̀ ti a fi mu ara wa binu, ti a sì ṣe ilara si ara wa. Ará mi, bi ẹnikan ninu nyin ba ṣubu lojiji sinu ẹ̀ṣẹ, ki ẹnyin ti iṣe ti ẹmí ki o mu irú enia bẹ̀ bọ̀ sipò nipa ẹmí ìwatutù, ki iwọ ki o sì mâ kiyesara rẹ, ki a má ba dán ọ wò pẹlu. Ẹ mâ rù ẹrù ọmọnikejì nyin, li ọ̀na bayi ni ẹnyin o sì mu ofin Kristi ṣẹ. Nitori bi ẹnikan ba rò pe ẹni-nla li on, o ntàn ara rẹ̀ jẹ, nitori kò nilari. Ṣugbọn ki olukuluku ki o mọ̀ iṣẹ ara rẹ̀ daju, nigbanâ ni yio sì ri ogo ninu ara rẹ̀ nikan, kì sì ṣe ninu ẹlomiran ; nitori olukuluku yio rù ẹrù ara rẹ̀. Njẹ ki ẹniti a nkọ́ li ọ̀rọ Ọlọrun, ki o mâ fi ohun ini rẹ̀ ràn ẹniti nkọ́ni lọwọ́. Ẹ máṣe tàn ara nyin ; a kò lè fi Ọlọrun rerin. Nitori ohunkohun ti enia ba funrugbìn rẹ̀, on ni yio sì ká pẹlu. Bayi ni ẹniti o ba funrugbìn sinu ara rẹ̀, lati ara ni yio sì ká idibajẹ ; ṣugbọn ẹniti o ba funrugbìn sinu ẹmí, lati ẹmí ni yio sì kó ikorè ìye ainipẹkun. Ki ẹ má sì ṣe jẹ̀ kì agara da wa ni ṣiṣe rere, nitori ao kó ikorè, nigbati akokò ba de, bi awa kò ba ṣe ârẹ̀. Nitorinâ bi awa ti ri âye.

ẹ jẹ ki a mâ ṣôre fun gbogbo enia, ṣugbọn nipataki fun awọn ti igbagbọ́ kanna ṣọ di arâle Oluwa.

Graduali. Ohun rere ni lati mâ fi ọpẹ fun Oluwa, ati lati mâ kọrin iyìn si orukọ rẹ, Ọgaogo! lati mâ fi âmu rẹ hàn li owurọ, ati otitọ rẹ loru. Alleluia, alleluia. Oluwa li Ọlọrun ti o tobi, on sì li ọba nla ti gbogbo ilẹ aiyé. Alleluia.

Ihin rere (Luk. VII, 11).

Nigbanâ ni Jesu nlọ si ilú kan ti a npè ni Naini, awọn ọmọ-ẹhin rẹ pẹlu ọpọ enia sì mbá a lọ. Bi o sì ti sunmọ ẹnubode ilú nâ, sì kiyesi i, nwọn ngbé okú kan jade, ọmọkọnri kanṣoṣo nâ ti iyá rẹ, on sì jẹ opó; ọpọ awọn enia ilú nâ sì nsìn i lọ. Nigbati Oluwa sì ri i, âmu rẹ ṣe e, o sì wí fun u pe: Má sọkún mọ. O sì sunmọtosi o sì fọwọ́ kàn posi nâ. Awọn ti o rù u sì duroje O sì wípe: Ọmọkọnri, mo wí fun ọ: Dide. Okú nâ sì dide joko, o sì bèrẹsi ohun ifọ. Jesu sì fâ a le iyá rẹ lọwọ́. Ẹru sì ba gbogbo wọn, nwọn sì yìn Ọlọrun logo, wípe: Woli nla dide lârin wa, Ọlọrun sì bẹ awọn enia rẹ wò.

Ifitọrẹ. Ni diduro emi durode Oluwa, o kiyesi mi, o sì gbọ́ adura mi, o sì fi orin titún si mi li ẹnu, ani orin iyìn si Ọlọrun wa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki sakramenti mimọ́ rẹ ki o mâ

pa wa mọ́, ki o sì mà dâbobo wa kuro ninu gbogbo ikọlù èṣu ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Akara nâ ti emi o tifun nyin li ara ni nitori igbalà araiye.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki awa ki o mâ mọ́ iṣe ẹbun rẹ ọrun ninu ọkàn ati ara wa sibẹsibẹ, ki oyé awa tikalawa ki o mâṣe mu wa ṣiṣe mọ́, ṣugbọn ki ôre-ọfẹ ti sakramenti yi ki o lè mà ṣaju wa , ki o sì lè mâ ṣe amọ̀na wa nigbagbogbo : nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸRINDILOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ṣànu fun mi, nitoriti iwọ li emi nkigbe pè lojojumọ ; nitori iwọ, Oluwa, o jẹ inurere ati oniwâ tutù, o sì pọ̀ li ànu fun gbogbo awọn ti nkigbe pè ọ. *Ps.* Oluwa, dẹ eti rẹ silẹ si adura mi, ki o si da mi lohùn, nitoriti emi jẹ talakà ati alaini. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ôre-ọfẹ rẹ ki o mâ ṣaju wa, ki o si mâ tọ̀ wa lẹhin nigbagbogbo, ki o sì mu wa tẹramọ́ iṣẹ rere titi ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

ẹ jẹ ki a mâ ṣôre fun gbogbo enia, ṣugbọn nipataki fun awọn ti igbagbọ́ kanna ṣọ di arâle Oluwa.

Graduali. Ohun rere ni lati mâ fi ọpẹ fun Oluwa, ati lati mâ kọrin iyìn si orukọ rẹ, Ọgaogo! lati mâ fi ânu rẹ hàn li owurọ, ati otitọ rẹ loru. Alleluia, alleluia. Oluwa li Ọlọrun ti o tobi, on sì li ọba nla ti gbogbo ilẹ aiye. Alleluia.

Ihin rere (Luk. VII, 11).

Nigbanâ ni Jesu nlọ si ilú kan ti a npè ni Naini, awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pẹlu ọ̀pọ̀ enia sì mbá a lọ. Bi o sì ti sunmọ́ ẹnubode ilú nâ, sì kiyesi i, nwọn ngbé okú kan jade, ọmọkọnri kanṣoṣo nâ ti iyá rẹ̀, on sì jẹ opó; ọ̀pọ̀ awọn enia ilú nâ sì nsìn i lọ. Nigbati Oluwa sì ri i, ânu rẹ̀ ṣe e, o sì wí fun u pe: Má sọkún mọ́. O sì sunmọtosi o sì fọwọ́ kàn posi nâ. Awọn ti o rù u sì duroje O sì wípe: Ọmọkọnri, mo wí fun ọ: Dide. Okú nâ sì dide joko, o sì bẹ̀rẹsi ohun ifọ̀. Jesu sì fà a le iyá rẹ̀ lọwọ́. Ẹru sì ba gbogbo wọn, nwọn sì yìn Ọlọrun logo, wípe: Woli nla dide làrin wa, Ọlọrun sì bẹ̀ awọn enia rẹ̀ wò.

Ifitọrẹ. Ni diduro emi durode Oluwa, o kiyesi mi, o sì gbọ́ adura mi, o sì fi orin titún si mi li ẹnu, ani orin iyìn si Ọlọrun wa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki sakramenti mimọ́ rẹ ki o mâ

pa wa mọ́, ki o sì mâ dâbobo wa kuro ninu gbogbo ikọlù èṣu ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Akara nâ ti emi o fifun nyin li ara ni nitori igbalà araiye.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki awa ki o mâ mọ́ iṣe ẹbun rẹ ọrun ninu ọkàn ati ara wa sibẹsibẹ, ki oyé awa tikalawa ki o máṣe mu wa ṣiṣe mọ́, ṣugbọn ki ôre-ọfẹ ti sakramenti yi ki o lè mâ ṣaju wa , ki o sì lè mâ ṣe amọ̀na wa nigbagbogbo ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸRINDILOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ṣânu fun mi, nitoriti iwọ, li emi nkigbe pè lojojumọ ; nitori iwọ, Oluwa, o jẹ inurere ati oniwà tutù, o sì pọ̀ li ânu fun gbogbo awọn ti nkigbe pè ọ. *Ps.* Oluwa, dẹ eti rẹ silẹ si adura mi, ki o si da mi lohùn, nitoriti emi jẹ talakà ati alaini. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ôre-ọfẹ rẹ ki o mâ ṣaju wa, ki o sì mà tọ wa lẹhin nigbagbogbo, ki o sì mu wa tẹramọ́ iṣẹ rere titi ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Efesi. 3).

Arà mi, mo bẹ̀ nyin ki ẹ máṣe fòya nitori wahalà mi ti mo jẹ nitori nyin, ti iṣe ogo nyin. Nitori idi yi ni mo ṣe ntẹ̀ èkun mi bà niwaju Baba Oluwa wa Jesu-Kristi, ẹniti iṣe olupilẹṣẹ ati olori ti gbogbo idile nla ti mbẹ li ọrun ati li aiye yi, ki On ki o lè fifun nyin, gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ọrọ̀ ogo rẹ̀, ki a lè fi ipá mu nyin lagbara niti enia inu nipa Ẹmí rẹ̀, ki Kristi ki o lè mà gbé inu ọkàn nyin nipa igbagbọ́; pe lehin igbati a ti fi ẹsẹ̀ nyin mulẹ, ti a sì ti fi idi nyin kalẹ ninu ifẹni, ki o lè yé nyin pẹlu gbogbo awọn Enia Mimọ́ kini ibú, gigùn, giga ati jijin ti ọ̀rọ ijinlẹ ti inu rere Ọlọrun si awọn enia; ki ẹnyin ki o sì lè mọ̀ ifẹ Kristi si wa, ti o rekoja jù gbogbo imọ̀ lọ, ki ẹnyin ki o lè kún fun gbogbo ẹbun Ọlọrun, ṣugbọn fun ẹniti o lè ṣe ọ̀pọlọpọ jù gbogbo eyiti a mbère tabi ti a nrò lọ, gẹgẹbi agbara ti nṣiṣẹ ninu wa, on ni ki a mà fi ogo fun ninu Eklesia nipa Jesu-Kristi lati irandiran gbogbo aiye ainipẹkun. Amin.

Graduali Awọn keferi yio mà bẹ̀ru orukọ rẹ, Oluwa, ati gbogbo awọn ọba aiye yi yio si mà bẹ̀ru ogo rẹ. Nitori Oluwa ti gbé Sioni ró, ao sì ri I ninu ogo rẹ̀. Alleluia, alleluia. Ẹ kọrin titun si Oluwa, nitoriti o ti ṣe ohun iyanu. Alleluia.

Ihin rere (Luk. xiv, 1).

Nigbanâ ni Jesu wọ̀ ile ọkan awọn olori

Farisi lọ lati jẹun li ojọ́ isimi, awọn ti o wà nibẹ̀ sì nṣọ́ Ọ. Sì kiyesi i, ọkọnrin kan mbẹ niwaju rẹ̀, ti o ni asunkún ; Jesu sì dahùn, o wí fun awọn amofin ati awọn Farisi pe : O ha tọ́ lati mu ni larada li ọjọ́ isimi bi ? Nwọn sì dakẹ. Jesu sì mu ọkọnrin nâ li ọwọ́, o mu u larada o sì jọwọ rẹ̀ lọwọ́ lọ. Lẹhin eyi O bi wọn lère wipe : Tani ninu nyin ti yio ri kẹtẹkẹtẹ, tabi malu rẹ̀ ti o bọ sinu kanga, ti kì yio sì fà a soke lojukanna li ọjọ́ isimi ? Nwọn kò sì lè da a lohùn. O sì pa owe kan fun awọn alapèjẹ, nigbati o wò bi nwọn ti nyàn ipò ọlá, o sì wí fun wọn pe : Nigbati ẹnikan ba pè ọ si ibi iyawo, máṣe joko ni ipò ikini, nitoripe bi ao ba pè ẹni ti o li ọlá jù iwọ lọ, ki ẹniti o pè tìwọ tirẹ̀ ki o má ba wá wí fun ọ pe : Fun ọkọnrin yi li àye ; ati nigbanâ ki iwọ ki o má ba fi itiju mú ipò ẹhin. Ṣugbọn nigbati a ba pè ọ, lọ joko ni ipò ẹhin, pe nigbati ẹniti ọ pè ba de, ki o lè wí fun ọ pe : Ọrẹ́, bọ soke, nigbanâ ni iwọ o ní iyìn loju awọn ti o bá o joko tì onjẹ ; nitori ẹnikẹni ti o ba gbé ara rẹ̀ ga, ao rẹ̀ ẹ silẹ̀, ẹnikẹni ti o ba sì rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ̀, ao sì gbé e ga.

Ifitọrẹ. Oluwa, fiyesi i lati ràn mi lọwọ́ ; jẹ ki oju ki o tì awọn ti nwá ọkàn mi lati pa a run, ki nwọn ki o sì dàmu ; Oluwa, fiyesi i lati ràn mi lọwọ́.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, àwa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ̀, wẹ̀ wa mọ́ nipa agbara ẹbọ yi, ki o sì tifun wa, nipa ânu rẹ̀ ki awa ki o lè yẹ lati jẹ alabapin ninu rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa, emi o mâ ranti ododo rẹ nikan. Ọlọrun, iwọ ti kọ́ mi lati igba ewe mi wá ; máṣe kọ̀ mi silẹ, nigbati mo di arugbo tán, ti mo hewú

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, nipa ânu rẹ wẹ̀ ọkàn wa mọ́, ki o sì tún wọn ṣe nipa sakramenti ọrun yi, pe nipa rẹ̀ ki awa ki o lè ri iranlọwọ́ gbà fun ara wa li aiye yi ati li aiye ti mbọ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸTA-DILGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Olododo ni iwọ, Oluwa, otitọ sì ni idajọ rẹ ; ṣe si iranṣẹ rẹ gẹgẹ bi ânu rẹ. *Ps.* Alabukúnfun li awọn ti o pa ara wọn mọ́ ni mimọ́ li ọna nâ, ti o sì nrìn ninu ofin Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fi ôre-ọfẹ fun awọn enia rẹ lati sá fun ibajẹ aiye yi ati ti ẹṣu, ati pelu ọkàn ati inu funfun lati mà tọ̀ ọ lẹhin, iwọ Ọlọrun kanṣoṣo; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Efesi iv, 1.).

Arà mi, emi ti iṣe ondè nitori Oluwa mbẹ̀

nyin pe, ki ẹnyin ki o mà rìn bi o ti yẹ fun ìpe ti a pè nyin si. Ẹ mà ni irẹlẹ ọkàn, inu tutù pẹlu ipamọra ninu ohunkohun ; ki ẹnyin ki o sì fi sùru gbà ọmọnikeji nyin nipa ifẹni ; ki ẹnyin ki o si mâ teramọ́ lati pa isọkan ẹmí mọ́ ni ìdipọ̀ alafia. Ara kan ati ẹmí kan ni gbogbo nyin ise, gẹgẹ bi a ti pè nyin si ireti kan ninu ìpe nyin. Oluwa kan, igbagbọ́ kan, ibatisi kan ni mbẹ. Ọlọrun kanṣoṣo sì ni mbẹ, Baba gbogbo enia, ẹniti o wà lori gbogbo enia, ati làrin ohun gbogbo ati ninu gbogbo wa ; on ni a mâ fi ibukún fun lai ati lailai.

Graduali. Alabukúnfun li orilẹ-ède nâ ti o ni Ọlọrun bi Oluwa ; alabukúnfun sì ni awọn enia nâ ti Ọlọrun ti yàn bi ohun iní rẹ̀ ! Nipa ọ̀rọ̀ Ọlọrun li a dá awọn ọrun, gbogbo ẹwà wọn sì ti imí ẹnu rẹ jade wá. Alleluia, alleluia. Gbọ́ adura mi, Oluwa, ki o sì jẹ ki igbe mi ki o wá sọdọ rẹ. Alleluia.

Ihin rere (Mat. xxii, 35).

Nigbanâ ni awọn Farisi wá sọdọ Jesu, ọkan ninu wọn ti ise amofin sì bi i lèrè lati dán a wò, o wipe : Olukọ́ni, ewo ni ofin ti o tobi julọ ninu ofin ? Jesu sì wí fun u pe : Ki iwọ ki o fi gbogbo àiya rẹ, ati gbogbo ọkàn rẹ, ati gbogbo inu rẹ fẹ́ Oluwa Ọlọrun rẹ. Eyi ni ekini ati eyiti o tobi julọ. Ekeji sì dabi rẹ̀ : Ki iwọ ki o fẹ́ ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ. Gbogbo ofin ati gbogbo ọ̀rọ̀ Ọlọrun ti awọn woli ti sọ li o wà ninu ofin mejeji wọnyi. Bi awọn Farisi ti kó ara wọn jọ, Jesu bi wọn lèrè wipe : Kini

ẹnyin nrò ti Kristi si? Ọmọ tani iṣe? Nwọn wí fun u pe : Ọmọ Dafidi ni. O wí fun wọn pe, èha ti ṣe ti Dafidi nipa imísi Ẹmi-Mimọ fi pè e li Oluwa rẹ̀ wipe : Oluwa wí fun Oluwa mi pe : Iwọ joko li ọwọ́ ọtún mi, titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti ìtisẹ rẹ? Nje bi Dafidi ba npè e li Oluwa rẹ̀, èha ti ri ti o fi ṣe ọmọ rẹ̀? Kò si ẹnikan ti o lè da a lohùn ọ̀rọ kan, bẹ̀ni kò si si ẹniti o bi i lère ohun kan mọ́ lati ọjọ́ nà lọ.

Ifìtorẹ Emi Danieli gbadura si Ọlọrun mi, mo sì wipe : Oluwa, gbọ́ adura ọmọ-ọdọ rẹ, ki o sì mu ki imọlẹ oju rẹ ki o hàn si ibi mimọ́ rẹ ; ki o sì fi ânu wò awọn enia rẹ, nitori ẹniti a ti kigbe pè orukọ rẹ, Ọlọrun.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, awa nfi irẹlẹ ọkàn bèbẹ lọdọ Olá nla rẹ, je ki ohun ijinlẹ mimọ́ yi ti a ṣe lọwọ́ ki o lè wẹ̀ wa mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ ti igba ti o kọja, ki o sì lè pa wa mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ ti igba ti mbọ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. E ṣe ileri ifẹ́, ki ẹ sì je olôtọ lati san a fun Oluwa, Ọlọrun nyin ; je ki gbogbo nyin ti o yí altari rẹ̀ ká ki o mu ẹbun wá fun Ọlọrun ti o dì ẹru fun awọn ọba aiye.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, je ki sakramenti mimọ́ rẹ ki o mu wa larada kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa, ki a sì lè ri ohun imularada gbà ti o lè ṣe anfani fun iye ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KEJIDILOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ti alafia rẹ fun awọn ti nti sùru durode ọ, ki a le bá awọn woli rẹ ki nwọn ki o mâ ṣe ololùtọ; gbọ́ adura iranṣẹ rẹ ati ti Israeli, awọn enia rẹ. *Ps.* Inu mi dùn nigbati nwọn wí fun mi pe: ao lọ si ile Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, mâ tọ́ wa, ki o si mâ ṣakoso aiya wa nipa iṣẹ ânu rẹ, nitori a kò lè wù Ọ laisi rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (I Kor. I, 4).

Ará mi, mo ndupẹ lọwọ Ọlọrun mi nigbagbogbo fun nyin, nitori ôre-ọfẹ Ọlọrun ti a fifun nyin ninu Kristi Jesu, nitoripe nipaṣe rẹ li a kún nyin fun onirùru ọ̀rọ̀, gbogbo ẹbun ọ̀rọ̀ ati imọ̀. Bayi ni a ti fi idi ẹri Kristi kalẹ ninu nyin, tobẹ̀ ti ẹnyin kò fi rèhin ninu ẹbunkẹbùn rẹ̀, ẹnyin ti nreti ifarahàn Jesu-Kristi Oluwa wa. Ọlọrun yio si mu nyin duro ṣinṣin titide opin, ki ẹnyin ki o lè jẹ alailẹgàn li ọjọ́ Jesu-Kristi Oluwa wa.

Graduali. Inu mi dùn nigbati nwọn wí fun mi pe: ao lọ si ile Oluwa. Jẹ ki alafia ki o wà ninu odi rẹ, ati ọ̀pọ ninu âfin rẹ. Alleluia,

alleluia. Oluwa, awọn keferi yio mâ bẹ̀ru orukọ rẹ, ati gbogbo ọba aiye yio mâ bẹ̀ru ogo rẹ. Alleluia.

Ihin rere (Mat. IX, 1.)

Nigbanâ ni Jesu bọ sinu ọkọ̀, o là adagún kọja, o sì wá si ilú on tikalarẹ̀. Si kiyesi i, nwọn gbé ọkọnri alarùn ẹ̀gba kan ti o dubulẹ lori akete wá sọdọ rẹ̀ Nigbati Jesu ri igbagbọ́ wọn, o wí fun alarùn ẹ̀gba pe : Ọmọkọnri, túju ka, a dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ. Si kiyesi i, awọn ọkan ninu awọn akowe nwí ninu ara wọn pe : Ọkọnri yi nsọ ọ̀rọ̀ odi si Ọlọrun. Ṣugbọn bi Jesu ti mọ̀ iro inu wọn, o wí fun wọn pe : Ẹṣe ti ẹnyin fi nrò buburu ninu nyin? Ewo li o rọrùn jù lati wí pe : A dari ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ, tabi lati wí pe : Dide, ki o si mâ rìn. Ṣugbọn ki ẹnyin ki o lè mọ̀ pe, Ọmọ enia li agbara li aiye lati dari ẹ̀ṣẹ jini, (nigbanâ ni o wí fun alarùn ẹ̀gba nâ pe), Dide, gbé akete rẹ, ki o si mâ lọ si ile rẹ. O si dide, o si lọ si ile rẹ̀. Nigbati ijọ enia si ri i, ẹ̀ru bà wọn, nwọn si yìn Ọlọrun logo ti o fi irú agbara bayi fun awọn enia.

Ifitọrẹ. Mose ti yà altari kan si mimọ́ fun Oluwa; o ru ẹbọ sisun, o si pa ẹran lati fi rubọ lori rẹ; o si ru ẹbọ aṣàlẹ lati ṣe ôrun didùn si Oluwa Ọlọrun, niwaju awọn ọmọ Israeli.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Ọlọrun. Iwọ ti o sọ wa di alabapín ninu ìwa Ọlọrun rẹ mimọ́ nipasẹ ẹbọ ọlọlá yi, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, fifun ni, pe bi a ti mọ̀ otitọ rẹ,

bę̀ gęgę ni ki a lè de ọdọ rę nipa ihùwa mimọ́; nipasę Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ę mu ęran ębọ wá, ki ę sì wá si agbala rę̀, ki ę sì mâ foribalę fun Oluwa ninu âfin mimọ́ rę̀.

Adura lęhin komunioni.

Oluwa, awa ndupę fun Ọ nitoriti ti iwọ fi ębun mimọ́ rę bọ́ wa, awa sì mbębę lọdọ ânu rę, ki iwọ ki o sọ wa di yiyę lati mâ ję alabapín ninu rę̀ sibęsibę; nipasę Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KỌKAN DILOGUN LĘHIN PENTEKOSTI

Ipilęsę ti Misa. Emi ni igbalà awọn enia mi, ni Oluwa wí; ninu ipọnjukipọnju ti nwọn o kigbe pè mi, emi o gbọ́ adura wọn, emi o sì mâ sę Oluwa wọn titilai. *Ps.* Ẹnyin enia mi, ę fetisi ofin mi, ki ę sì dę etí nyin silę si ọrọ ẹnu mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati alânu julọ, nipa ânu rę pa wa mọ́ kuro ninu ohun gbogbo ti o lodi si igbalà wa, ki ohunkohun mâsę lè dawa duro li ara ati li ọkàn lati mâ fi inudidùn sę ohun wọnyi ti isę ti isìn rę; nipasę Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Efesi iv, 23).

Ará mi, ẹ di titun ninu ọkàn nyin, ki ẹnyin ki o sì gbé enia titún ni wọ, eyiti a da nipa ti Ọlọrun li ododo ati otitọ ìwa mimọ. Nitorinâ ẹ fi eke ṣiṣẹ silẹ; ki olukuluku nyin ki o mâ sọ otitọ fun ọmọnikeji rẹ; nitori ẹya ara ọmọnikeji wa li awa iṣe. Bi ẹnyin binu, ẹ máṣe ṣẹ. Ẹ máṣe jẹ ki ôrùn wọ ba ibinu nyin. Ẹ máṣe fi àye fun èṣu. Ki eniti o ti njale ri ki o máṣe jale mọ; ṣugbọn ki o kuku mâ ṣiṣẹ, ki o sì mâ fi ọwọ rẹ ṣe ohun ti o dara, ki on ki o lè ni nkan lati fifun awọn ti o wà ninu ainí.

Graduali. Oluwa, jẹ ki adura mi goke wá siwaju rẹ bi turari, ki igbé ọwọ mi soke si jẹ atẹwọgbà fun ọ bi ẹbọ aṣàlẹ. Alleluia, alleluia. Ẹ fi iyìn fun Oluwa, ki ẹ sì kigbe pè orukọ rẹ; ẹ róhìn iṣẹ rẹ làrin awọn orilẹ-ède. Alleluia.

Ihin rere (Mat. xxii, 2).

Nigbanâ ni Jesu tún fi owe sọrọ fun awọn olori alufa ati awọn Farisi pe: Ijọba ọrun dabi ọba kan ti o ṣe igbeyawo fun ọmọ rẹ. O sì rán awọn iranṣẹ rẹ lọ ipè awọn alapèjẹ si ibi iyawo; ṣugbọn nwọn kò lati wá. O tún rán awọn iranṣẹ miran, o sì wipe: Ẹ wí fun awọn alapèjẹ pe: Kiyesi i, mo ti mura asè mi tán, a pa malu ati gbogbo ẹran abọpa mi, a sì ṣe ohun gbogbo tán, ẹ wá si ibi iyawo. Ṣugbọn nwọn kò náni eyi, nwọn sì ba tiwọn lọ, ọkan lọ si oko rẹ, omiran si ọna owó rẹ. Awọn iyokù sì mu awọn iranṣẹ rẹ, nwon ṣe àbukùn si wọn,

nwọn sì pa wọn. Nigbati ọba sì gbọ́ eyi, o binu, o rán awọn ọmọ-ogun rẹ̀ lọ, o pa awọn apania wọnyi run, o sì kun ilú wọn. Nigbanâ li o wí fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe : A ṣe asè iyawo tán, ṣugbọn awọn ti a ti pè si i kò yẹ fun u. Nitorinâ ẹ lọ si ọ̀na opópo, ẹnikẹni ti ẹ ba ri, ẹ pè e wá si ibi iyawo. Awọn iranṣẹ rẹ̀ sì jade lọ si ọ̀na opópo, nwọn sì kó gbogbo awọn ẹniti nwọn ri jọ, awọn buburu ati awọn rere, ibi iyawo sì kún fun awọn alapèjẹ. Lẹhinnâ ọba nâ wọ̀le lọ lati wò awọn alapèjẹ, o sì ri ọkọnri kan nibẹ̀ ti kò wọ̀ aṣọ iyawo, o sì wí fun u pe : Ọrẹ́, bawo ni iwọ ti ṣe wọ̀ ihin wá laini aṣọ iyawo? Kò sì lè fọhùn. Nigbanâ li ọba wi fun awọn iranṣẹ rẹ̀ pe : Ẹ dì i tọwọ́ tẹsẹ̀, ki ẹ sì gbé e sọ sinu òkunkun ode : nibẹ̀ ni ẹkún ati ipahin-keke yio gbé wà. Nitori ọ̀pọ̀lọpọ̀ li a pè, ṣugbọn diẹ̀ li a yàn.

Ifitọrẹ. Bi emi tilẹ nrìn ninu ipọnju, iwọ ni yio pa ẹmi mi mọ́, Oluwa ; iwọ o nà ọwọ́ rẹ si ibinu awọn ọtá mi, ọwọ́ ọtún rẹ yio sì gbà mi là.

Adura ti a hà jejẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, fifun ni, ki ẹ̀bun ti a ru lẹbọ si Ọlá nla rẹ mimọ́ ki o lè mâ ṣe anfani fun igbalà ọkàn wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Iwọ ti pasẹ pe ki a pa ofin rẹ mọ́ bi o ti yẹ, nitorinâ fiyesi i, Oluwa, lati ṣakoso ọ̀na mi tobẹ̀ ti emi mâ fi pa ofin rẹ mọ́.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, fifunni nipa ânu rẹ, ki agbara ôreọfẹ imularada rẹ ki o lè gbà wa kuro ninu èṣẹ wa, ki o sì lè mu ki a mâ rìn nigbaghogbo li ọna ofin rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ OGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, ohunkohun ti iwọ ti ṣe, ni iwọ ti ṣe nipa idajọ ododo ati otitọ; nitori awa ti ṣẹ si ọ, a sì ti ṣaigbọran si ofin rẹ. Ṣugbọn, Oluwa, fi ogo fun orukọ rẹ, ki o sì ṣe si wa gẹgẹ bi ọpọ ânu rẹ. *Ps.* Alabukúnfun fi awọn ti o pa ara wọn mọ ni mimọ li ọna nâ, ti o sì nrìn ninu ofin Oluwa! Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ninu ânu rẹ fun awọn onigbagbọ rẹ li idarijì èṣẹ wọn ati alafia, ki a lè wẹ wọn nù kuro ninu gbogbo èṣẹ wọn, ki nwọn ki o sì mâ fi ifaiyabalẹ sìn Ọ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Efesi v, 15).

Ará mi, ẹ kiyesi lati mâ fi iwoye rìn, ki iṣe bi awọn alaimoye, ṣugbọn bi awọn amoye; ẹ mâ rà ìgba pada, nitori buburu li awọn ọjọ. Nitorinâ ki ẹ má ṣe alaimoye, ṣugbọn ẹ mâ

moye ohun ti ifẹ Oluwa jasi. Ẹ máṣe mu ọti vini li amupara, ninu eyiti ijaiye ifẹkufẹ ara ti yọ jade wá, ṣugbọn ẹ kún fun Emi-Mimọ, ki ẹ si mâ ba ara nyin sọrọ ninu mimọ, orin iyìn, ati orin nipa ti ẹmí; ẹ mâ korin, ki ẹ si mâ fi tọkàntọkàn hó ihó ayọ si ogo Oluwa; ẹ mâ dupẹ nigbagbogbo nitori ohun gbogbo lọwọ Ọlọrun Baba li orukọ Oluwa wa Jesu-Kristi. Ẹ mâ tẹriba fun ara nyin ni ibẹru Kristi.

Graduali. Oju gbogbo ẹdá nwò ọ, Oluwa, iwọ si fun wọn li onjẹ wọn li akokò rẹ. Iwọ ṣí ọwọ rẹ, iwọ si kún gbogbo ẹdá alâye fun ibukún rẹ. Alleluia, alleluia. Ọkàn mi mura tán, Ọlọrun, ọkàn mi mura tán; emi yio kọrin emi yio si fi orin yìn ọ, ogo mi. Alleluia.

Ihin rere (Joh. IV, 46).

Nigbanâ ni ijoyè kan wà, ẹniti ara ọmọ rẹ kò dá ni Kafarnaumu. Nigbati o ti gbọ pe, Jesu ti Judea jade wá si Galili, o tọ Ọ wá, o si mbẹ ẹ ki o sọkalẹ wá lati mu ọmọ on larada, nitoriti o nkú lọ. Jesu si wí fun u pe: Bikoṣe pe ẹnyin ba ri àmi ati iṣẹ iyanu, enyin kì yio gbagbọ. Ijoyè nâ wí fun u pe: Oluwa, sọkalẹ wá, ki ọmọ mi ki o to kú. Jesu wí fun u pe: Mâ ba ọna rẹ lọ, ọmọ rẹ yè. Okọnri nâ gbà ọrọ ti Jesu sọ fun u gbọ, o si ba tirẹ lọ. Bi o si ti nsọkalẹ lọ, awọn iranṣẹ rẹ pade rẹ, nwọn si wí fun u pe: Ara ọmọ rẹ ti dá. Nigbanâ ni o bère wakati ti o bẹrẹ si san lọwọ wọn. Nwọn si wí fun u pe: Lanà, ni wakati keje ọjọ ni ibà

nâ fi i silẹ. Nigbanâ ni baba nâ mọ pe wakati kannâ gan ni ninu eyiti Jesu wí fun u pe : Ọmọ rẹ yè. Ontikalarẹ sì gbagbọ, ati gbogbo ile rẹ.

Ifitọrẹ. Lẹba odò Babiloni li a gbé joko, awa sì sọkun, nigbati awa ranti Sioni.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ohun ijinlẹ mimọ wọnyi ki o sì lè jẹ ohun imularada ọrun fun wa, ki o sì lè wẹ ọkàn wa nù kuro ninu ìwa buburu ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa, ranti ileri rẹ ti iwọ ti ṣe fun iranṣẹ rẹ ; eyi nâ ni mo gbẹkẹle ; o sì tù mi ninu ninu ipọnju mi.

Adura lẹhin komunioni.

Ki awa ki o lè mâ yẹ lati jẹ alabapín ninu ẹbun rẹ mimọ, Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifun wa, ki a mà pa ofin rẹ mọ nigbagbogbo ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KỌKAN LELOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ohun gbogbo mbẹ ni ifé rẹ, Oluwa ; kò si ẹniti o lè kọjujàsi ifé rẹ : nitori

iwọ li o dá ohun gbogbo, ọrun on aiye, ati ohun gbogbo ti mbẹ labẹ ọrun : iwọ ni Oluwa gbogbo ilẹ aiye. *Ps.* Alabukúnfun li awọn ti o pa ara wọn mọ ni mimọ li ọna nâ, ti o sì nrìn ninu ofin Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, nipa ânu rẹ pa awọn enia rẹ mọ titilọ, pe nipasẹ iranlọwọ rẹ ki nwọn ki o lè bọ kuro ninu gbogbo ipọnju, ki nwọn sì mâ fi ogo fun orukọ rẹ nipa ṣiṣe iṣẹ rere ; nipasẹ Jesu Kristi, Oluwa wa Amin.

Epistoli (Efesi VI, 10).

Eyin ará mi, ẹ jẹ alagbara ninu Oluwa ati ni ipá agbara rẹ. Ẹ mu gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ, ki eyin ki o lè kojujàsi ètan ati arekereke èṣu. Nitoripe kì iṣe ẹran ara ati ẹjẹ li awa ni lati ba jà nikan, ṣugbọn awọn ọmọ-alade, awọn alagbara, awọn alakoso aiye ti mbẹ ninu òkunkun yi, awọn ẹmí buburu ti mbẹ ni ofurufu. Nitorinà ẹ mu gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ, ki eyin ki o lè duro jà li ọjọ buburu ti idánwò, ki ẹ sì lè duro ṣinṣin laiyẹsẹ. Nitorinà ẹ mà mura silẹ, ẹ fi otitọ di egbẹ nyin li àmure, ki ẹ sì di ẹwu irin ti ododo ni mọra, ki ẹ sì wọ ẹsẹ nyin ni bàta la'i mura fun iwâsu Ihin rere ti alafia. Jù gbogbo rẹ lọ, ẹ mu apata igbagbọ, nipasẹ eyiti eyin o fi lè mâ paná gbogbo ọfà iná ti ẹmí buburu ni, ki ẹ sì mu a aṣibori irin ti igbalà, ati idà Ẹmí nì, ti iṣe ọrọ Ọlọrun.

Graduali Oluwa, iwọ li o ti nṣe ibi asálà wa lati irandiran. Ki a to dá awọn òke nla, ati ki iwọ ki o to dá ilẹ ati aiye, iwọ li Olọrun lati aiyeraiye. Allelnia, alleluia Nigbati Israeli jade kuro ni ilẹ Egipti, ti ará ile Jakọbu kuro ninu orilẹ-ède àjeji, Olọrun yà orilẹ-ède awọn Ju si mimọ fun isìn rẹ. Alleluia.

Ihin rere (Mat. XVIII, 23).

Nigbanâ ni Jesu pa owe yi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : Ijoba ọrun dabi ọba kan ti nfẹ ba awọn ọmọ-ọdọ rẹ ṣe isiro. Nigbati o bẹrẹsi isiro, a mu ọkan tọ ọ wá, ti o jẹ ẹ ni ẹgbarun talenti (ti o to iwọn adọta dilẹgbẹta ọkẹ pọundi). Ṣugbọn bi kò ti ni nkan lati fi san a pada, oluwa rẹ paṣẹ pe, ki a tà a, ati obirin rẹ, ati awọn ọmọ rẹ, ati ohun gbogbo ti o ni, lati fi san gbèse nâ. Nigbanâ ni ọmọ-ọdọ nâ wólẹ lẹba ẹṣẹ rẹ, o si bẹ ẹ, wipe : Oluwa, mu sùru fun mi, emi o si san gbogbo rẹ fun ọ. Nigbanâ ni oluwa ṣânu fun ọmọ-ọdọ nà, o jọwọ, o si fi gbèse nâ ji i. Ṣugbọn nigbati ọmọ-ọdọ nâ jade lọ, o ri ọkan ninu awọn iranṣẹ ẹgbẹ rẹ, ti o jẹ ẹ li ọgọrun owo idẹ (ti o to iwọn pọundi meji); o di i mu, o fún u li ọrùn, o wipe : San gbèse ti iwọ jẹ mi. Iranṣẹ rẹ si wólẹ lẹba ẹṣẹ rẹ, o bẹ ẹ, wipe : Mu sùru fun mi, emi o san gbogbo rẹ fun ọ. Ṣugbọn on kò fẹ, o si lọ, o si gbé e sọ sinu tubu, titi yio fi san gbèse nâ. Nigbati awọn iranṣẹ ẹgbẹ rẹ ri eyiti o ṣe, ânu ṣe wọn gidigidi, nwọn si lọ sọ gbogbo ohun ti a ṣe fun oluwa wọn. Nigbanâ ni oluwa rẹ pè e, o si wí fun u pe : Iwọ iranṣẹ buburu yi, mo ti fi gbo-

gbo gbèse rẹ ni jì ọ, nitoriti iwọ bẹ mi : njẹ kò ha tọ ki iwọ pẹlu ki o ṣànu fun iranṣẹ egbẹ rẹ, gẹgẹ bi mo ti ṣànu fun ọ bi? Oluwa rẹ sì binu, o fi i le awọn adanilóro lọwọ titi yio fi san gbogbo gbèse rẹ tán. Bẹ gẹgẹ ni Baba mi ti mbẹ li ọrun yio ṣe si nyin, bi olukuluku nyin kò ba fi tọkàntọkàn rẹ dari ẹṣẹ jì arakọnri rẹ.

Ifitọrẹ. Ọkọnri kan ti wà ni ilẹ Usi, orukọ ẹniti ijẹ Jobu ; ọkọnri nà sì sẹ olótọ, alailẹgan, o sì bẹru Ọlọrun. Eṣu sì bère aṣẹ lọwọ Oluwa lati dán a wò ; Oluwa sì fi ohun ini ati ara rẹ si ikawọ rẹ : on sì pa gbogbo ohun ini ati awọn ọmọ rẹ run, o sì fi ôwo kikankikan pọn ara rẹ loju.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi ojurere gbà ẹbọ yi, nipa eyiti o wù ọ lati rẹ ibinu rẹ silẹ, ati lati tún fun wa li igbalà nipa ânu rẹ alagbara ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ọkàn mi ndurode iràntọwọ rẹ. emi sì ngbẹkẹle ọrọ rẹ. Nigbawo ni iwọ o ṣe idajọ lara awọn ti nṣe inunibini si mi. Awọn enia buburu ti ṣe inunibini si mi ; ràn mi lọwọ, Oluwa, Ọlọrun mi.

Adura lẹhin komunioni.

Bi awa ti ri onjẹ aikú gbà, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, Oluwa, jẹ ki awa ki o lè fi ọkàn mimọ fàmọ ohun ti a ti fi ẹnu wa gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KEJI LELOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, bi iwọ ba kiyesi ẹṣẹ wa, tani yio lè duro niwaju rẹ? Ṣugbọn iwọ kún fun ânu, Ọlọrun Israeli. *Ps.* Lati inu ibú wá li emi kigbe pè ọ, Oluwa ; Oluwa, gbohùn mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, âbo ati agbara wa, Iwọ ti iṣe olorisun gbogbo ifọkànsìn ; ti ojurere gbọ́ adura Eklesia rẹ, ki o si fifunni ki ohun wọnyi ti awa nfi igbagbọ́ bère, ki a lè mâ ri wọn gbà laitase ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Filipi 1, 4).

Ẹnyin ará mi, mo ngbẹkẹle Oluwa Jesu pe, ẹniti o bẹ̀rẹ iṣẹ rere ninu nyin, yio si pari rẹ̀ titi yio fi di ọjọ́ Jesu-Kristi ; gẹgẹ bi o ti tọ́ fun mi lati rò eyi fun gbogbo nyin, nitoriti mo ni nyin li àiya mi, gbogbo nyin ti iṣe alabapín ninu ayọ̀ ti mo nní ninu ẹ̀wọn mi, ninu eyiti mo wà nitori igbijà, ati ifẹsẹ-mulẹ ti Ihin rere. Nitoripe Ọlọrun li ẹlẹ̀ri mi, bi mo ti nfẹ́ nyin gidigidi to ninu iyọ́nu Jesu-Kristi. Ohun ti mo si mbère lọwọ́ rẹ̀ ni pe, ki ifẹni nyin ki o lè mâ pọ̀ si i ninu imọ̀ ati gbogbo imoye, ki ẹnyin ki o lè yàn ohun ti iṣe rere julọ, ki ẹnyin ki o lè jẹ mimọ́ ati alailègan titi fi di ọjọ́ Kristi, ki ẹnyin ki o lè kún fun eso ododo nipasẹ Jesu-Kristi fun ogo ati iyìn Ọlọrun.

Graduali· Kiyesi i, bi o ti dara, bi o sì dùn to fun awọn ará lati mâ jumọ gbé ni irẹpọ̀! O dabi oróro iyebiye ti a ta si ọri Aaroni, ti o sì ṣàn de irungbọn rẹ̀. Alleluia, alleluia. Awọn ti o bẹ̀rù Oluwa ki nwọn gbẹkẹle e, on ni iranlọwọ́ ati asà wọn. Alleluia.

Ihin-rere (Mat. xxii, 15).

Nigbanâ li awọn Farisi lọ, nwọn sì gbìmọ bi nwọn o ti ṣe mu Jesu li ọ̀rọ rẹ̀. Nwọn sì rán awọn ọmọ-ẹhin wọn pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Herodu lọ sodọ rẹ̀, nwọn sì wipe : Olukọ́ni, awa mọ̀ pe olotitọ ni iwọ, iwọ sì nkọ́ni li ọ̀na Ọlọrun li otitọ, iwọ kò sì woju ẹnikẹni ; nitoriti iwọ kò ṣe isaju fun enia kan : njẹ wí fun wa bi iwọ ti rò o si ? O ha tọ́ lati mà san owode fun Sesari (ọba), tabi kò tọ́ bi ? Ṣugbọn bi Jesu ti mọ̀ ìro buburu wọn, o wí fun wọn pe : Enyin agabagebe wọnyi, èṣe ti enyin fi ndán mi wò ? E fi owode kan hàn mi. Nwọn sì fi kọpọ kan hàn fun u. Nigbanâ ni Jesu bi wọn lẽre pe : Aworan ati akọ́le tali eyi ? Nwọn da a lohùn wipe : Ti Sesari ni. Nigbanâ ni o wí fun wọn pe : Njẹ, nitorinâ ẹ fi ohun ti iṣe ti Sesari fun Sesari ; ati ohun ti iṣe ti Ọlọrun fun Ọlọrun.

Ifitọrẹ. Ranti mi, Oluwa, iwọ ti o jọba lori gbogbo ijọba aiye, ki o sì fi ọ̀rọ ti o dara si mi li ẹnu, ki ọ̀rọ mi ki o lè dara loju ọba,

Adura ti a kà jẹjẹ.

Ọlọrun alânu julọ, tifunni, ki ẹbọ ti igbalà

wa yi ki o lè mà wẹ wa nù nigbagbogbo kuro ninú ẹṣẹ awatikalawa, ki o sì mà pa wa mọ kuro ninu gbogbo ipọnju ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin

Komunioni. Emi ti nkigbe pè ọ, Ọlọrun mi, iwọ sì gbohùn mi ; dẹ etí rẹ silẹ, ki o sì gbọ́ adura mi.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa ti ri ẹbun ọ̀rọ ijinlẹ rẹ mimọ́ gbà, awa sì nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ ti iwọ ti pasẹ fun wa lati mà ṣe li iranti rẹ ki o lè ṣe iranlọwọ́ ailera wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IJỌ ỌSẸ KẸTA LELOGUN LẸHIN PENTEKOSTI.

Bi ijọ́ ọsẹ yi ba jẹ ikẹhin, ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ kẹrin lelogun lẹhin Pentekosti.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa wí pe : Mo rò ìro alafia, kì sì ṣe ti ipọnju : ẹnyin o kigbe pè mi, emi o sì túnmu awọn igbekun nyin pada bọ̀ lati ibi gbogbo ilẹ aiye wá. *Ps.* Oluwa, iwọ ti bukúnfun ilẹ rẹ ; iwọ ti mu igbekun Jakọbu dopin. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, dari ẹṣẹ awọn

enia rẹ jì wọn, pe nipasẹ ọpọlọpọ inu rere rẹ ki a lè yọ wa kuro ninu èwọn èṣẹ wọnyi ti a da nipa ìwa ailera wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Filipi III, 17).

Ẹnyin ará mi, ẹ mà ṣe alafarawé mi, ki ẹ sì mâ kiyesi awọn ti nhùwa gẹgẹ bi apẹrẹ ti awa ti ṣe fun nyin. Nitori ọpọlọpọ li o wà, ẹniti mo ti nsọrọ wọn fun nyin nigbakùgba (mo sì tún nsọrọ wọn fun nyin nisisiyi ti emi ti isokún), awọn ẹniti nhùwa bi ọtá ti agbelebu Jesu-Kristi, igbẹhin ẹniti yio sì ṣe iparun, ti nwọn ṣe ikún wọn ni Ọlọrun wọn, ti nwọn sì nsogo ninu itiju ara wọn tikalawọn, ti nwọn sì nni kìki ìro ati ifẹ si ohun ti aiye yi nikan. Ṣugbọn bi o ṣepe awa ni, aiye wa mbẹ li ọrun, lati ibẹ nâ li awa pẹlu gbé ádurode Olugbala, Oluwa wa Jesu-Kristi, ẹniti yio pa ara osi wa yi da, nipa sisọ ọ dabi ara ontikalarẹ ti o logo nipa iṣẹ agbara nà nipa eyiti o lè ti tèri ohun gbogbo ba fun ara rẹ. Nitorinâ, ẹnyin ara mi olufẹ ati ọwọn, ti iṣe ayọ ati adé mi, ẹ duro-sinsin niti Oluwa, ẹnyin olufẹ mi. Emi mbẹ Efodia, mo sì mbẹ Sintike ki nwọn ki o wà ni inu kannâ niti Oluwa. Mo sì mbẹ ọ pẹlu, iwọ ti iṣe olubaṣiṣẹ mi olòtọ, ràn awọn obirin wọnyi lọwọ, ti mbá mi ṣiṣẹ pọ ninu ifẹsẹ mulẹ ti Ihin rere, ati Klementi pẹlu, ati awọn olubaṣiṣẹ mi miran, orukọ awọn ẹniti mbẹ ninu iwe iye.

Graduali. Oluwa, iwọ li o ti gbà wa là lọwọ

awọn ti o pọ̀n wa loju, iwọ sì ti dojutì awọn ti o korira wa ; nitori Ọlọrun li awa a mâ ṣogo li ọjọ́ gbogbo, awa o sì mâ yìn orukọ rẹ lailai. Lati inu ibú wá li emi kigbe pè ọ, Oluwa ; Oluwa, gbohùn mi.

Ihin rere (Mat. IX, 18).

Nigbanâ, bi Jesu ti nsọ̀rọ fun ijọ awọn enia, sì kiyesi i, ijoye kan tọ̀ Ọ wá, o sì foribalẹ fun u, o sì wipe. Oluwa, ọmọbirin mi kú nisisiyi ; Sugbọn wá fi ọwọ́ rẹ le e, on o sì yè. Jesu sì dide, o sì tẹle e ti on ti awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀. Sì kiyesi i, obirin kan ti o nrùn ọ̀rin èjẹ fun ọdún mejila, o wá lẹhin rẹ̀, o sì fọwọ́ kàn iṣẹ́ti aṣọ rẹ̀ ; nitori o wí ninu ara rẹ̀ pe : Bi mo ba sá lè fi ọwọ́ kàn aṣọ rẹ̀, ara mi o dá. Nigbanâ ni Jesu yipada, o ri i, o sì wipe : Ọmọbirin, túju ka, igbagbọ́ rẹ ti mu ọ larada. A sì mu obirin nâ larada lati wakati nâ lọ. Nigbati Jesu sì de ile ijoye nâ, ti o sì ri awọn afunfère ati awọn enia ti npariwo, o wí fun wọn pe : Ẹ bìla, nitori ọmọbirin nâ kò kú, ṣugbọn sisùn li o sùn. Nwọn sì fi i rerin, Lẹhin igbati a sì ti tì awọn enia jade, o bọ́ sile, o sì fà ọmọbirin nâ li ọwọ́, on sì dide. Okiki nkan yi sì tànka ilẹ nâ gbogbo.

Ifitọrẹ. Lati inu ibú wá li emi kigbe pè ọ, Oluwa ; Oluwa, gbohùn mi ; lati inu ibú wá li emi kigbe pè ọ, Oluwa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa ru ẹbọ iyìn yi si ọ bi àmi itẹriba

wa fun ọ, ki o lè wù ọ lati mu ohun wọnyi ṣẹ ninu wa, ti iwọ ti fifun wa laisi èrekèrè kan nipatiwa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Lôtọ ni mo wí fun nyin pe : ohunkohun ti ẹnyin bère, nigbati ẹnyin ba ngbadura, ẹ gbagbọ́ pe ẹnyin o ri wọn gbà, ẹnyin o sì ni wọn,

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, máṣe jẹ ki awọn ẹniti o ni alafia nipa ôre-ọfẹ rẹ lati jẹ alabapin ninu onjẹ mimọ́ rẹ ṣubu sinu ewu aiye yi : nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Bi awọn ọsẹ lẹhin Pentekosti ba mâ rekoja jù mẹrinlelogun lọ, ao ṣe misa ti awọn ọsẹ lẹhin Epifani ti a ti fi silẹ, li ọna ti o tẹle wọnyi.

1° Bi o ba jẹ pe ọsẹ mẹdọgbọ̀n ni mbẹ, li ijọ́ ọsẹ kẹrin lelogun ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ ẹkẹfa lẹhin Epifani.

2° Bi o ba jẹ pe ọsẹ mẹrin dilọgbọ̀n ni mbẹ, li ijọ́ ọsẹ kẹrinlelogun ao ṣe misa ti ọjọ́ ọsẹ ẹkarun lẹhin Epifani ati li ijọ́ ọsẹ ẹkẹdọgbọ̀n ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ ẹkẹfa lẹhin Epifani.

3° Bi o ba jẹ pe ọsẹ mẹtadilọgbọ̀n ni mbẹ, li ijọ́ ọsẹ kẹrin lelogun ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ kẹrin lẹhin Epifani ; li ijọ́ ọsẹ kẹdọgbọ̀n ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ karun lẹhin Epifani ; ati li ijọ́ ọsẹ kẹrindilọgbọ̀n ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ kẹfa lẹhin Epifani.

4° Bi o ba jẹ pe ọsẹ meji dilọgbọ̀n ni mbẹ, li ijọ́ ọsẹ kẹrin lelogun ao ṣe misa ti ijọ́ kẹta lẹhin Epifani; li ijọ́ ọsẹ kẹdọgbọ̀n ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ kẹrin lẹhin Epifani; li ijọ́ ọsẹ kẹrin dilọgbọ̀n ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ ẹkarun lẹhin Epifani; ati li ijọ́ ọsẹ kẹta dilọgbọ̀n ao ṣe misa ti ijọ́ ọsẹ ẹkẹfa lẹhin Epifani.

Ati misa ti ijọ́ ọsẹ kẹrinlelogun ti a o ṣe nigbẹhin Sugbọn ipilẹṣẹ ti misa, graduali, ifitọrẹ ati komunioni ninu misa ti ijọ́ ọsẹ ti a da so yi, nwọn mâ ri bi ti ijọ́ ọsẹ ẹkẹtalelogun nigbagbogbo.

IJỌ ỌSẸ KẸRIN LELOGUN LẸHIN PENTEKOSTI

Ipilẹṣẹ, graduali, ifitọrẹ ati komunioni ri bi ti ijọ́ ọsẹ ẹkẹta lelogun.

Adura.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ru ifẹ awọn onigbagbọ́ rẹ soke si ifọkànsìn, ki nwọn ki o lè mâ ti ifara gbigbona julọ so eso iṣẹ rere, ki nwọn sì mâ yẹ nipa eyi nâ lati ri iranlọwọ́ ânu rẹ gbà lọpọ̀lọpọ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Kol. 1, 9).

Ẹnyin ará mi, awa kò dawọduro lati mà gbadura fun nyin, ati lati mà bère lọwọ́ Ọlọ-

run pe, ki o lè kún nyin fun ìmọ ifé rẹ, nipa fifun nyin li ọgbọn ati imoyé gbogbo ti Emí, ki ẹnyin ki o lè mâ hùwa li ọna ti o yẹ fun Ọlọrun, ki ẹnyin ki o lè wù Ú li ohunkohun, ki ẹnyin ki o lè so eso onirùru iṣẹ rere, ki ẹ sì lè mâ dàgba ninu ìmọ Ọlọrun; ki a lè kún nyin fun agbara li ohunkohun nipa agbara rẹ ti o logo, fun sùru ati iroju pelu ayọ; ki ẹ sì mâ dupẹ fun Ọlọrun Baba, ẹniti o ti mu wa yẹ nipa titàn imọlẹ rẹ si wa lati jẹ alabapín ninu ijogún awọn Enia mimọ; ẹniti o gbà wa kuro lọwọ agbara òkunkun, ti o sì ti ṣí wa nipò pada sinu ijọba Ọmọ rẹ ayanfẹ, nipa ẹjẹ ẹniti a ti rà wa pada, awa si ri idarijì èṣẹ wa gbà.

Ihin rere (Mat. xxiv, 15).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe: Nigbati ẹnyin ba ri irira isọdahoro ni, ti woli Danieli ti sọ tẹlẹ ni ibi mimọ ni (ẹnikẹni ti o ba kà a, ki oyé kio yé e), nigbanâ ni ki awọn ti mbẹ ni Judea ki o sá lọ sori òke; ki ẹniti mbẹ lori orule ki o máṣe sọkalẹ wá lati mu ohunkohun jade ninu ile rẹ; ki ẹniti mbẹ li oko ki o máṣe pada sẹhin wá lati mu aṣọ rẹ. Ṣugbọn egbé ni fun awọn obirin ti o lóyun ati fun awọn ti o nfi ọmú fun ọmọ mu ni ijọ wọnyi! Nitorinâ ẹ mâ gbadura ki àisá nyin ki o máṣe bọ si ìgba otutù, tabi si ọjọ isimi; nitori nigbanâ ni ipọnju nla yio wà, irú eyiti kò si lati ipilẹṣẹ aiye titidi isisiyi, irú rẹ ki yio sì si lai. Bi kò sì ṣepe a ke ọjọ wọnyi kuru, kò si enia kan ti iba lè là, ṣugbọn nitori awọn ayanfẹ li a fi ke ọjọ wọnyi kuru. Nigbanâ, bi

ẹnikan ba wí fun nyin pe : Wò o, Kristi mbẹ nihinyi, tabi lọhún, ẹ máṣe gbà a gbọ́. Nitori awọn Kristi eke ati woli eke ni yio dide ; nwọn yio sì ṣe àmi nla ati iṣẹ iyanu. tobẹ (bi o ba lè ṣe) ti nwọn iba fi tàn awọn ayanfẹ pâpa. Kiyesi i, mo wí nkan wọnyi fun nyin tẹlẹ. Nitorinà bi nwọn ba wí fun nyin pe : Sawò o, on wà ninu aginjù, ẹ máṣe jade lọ : Wò o, on wà ni ìkọkọ yará, ẹ máṣe gbà a gbọ́. Nitoripe gẹgẹ bi manamaná iti ìha ìla ôrùn jade, ti sì mọlẹ ni ìha ìwọ ôrùn, bẹ gẹgẹ ni wiwá Ọmọ-enia yio ri pẹlu. Nibikibi ti okú ba gbé wà, ibẹ li awọn idì kojọpọ́ si. Ṣugbọn lojukannà lẹhin ipọnju ti awọn ọjọ́ wọnyi li ôrùn yio ṣòkunkun, osupa kì yio sì tàn imọlẹ rẹ ; awọn irawọ yio ti oju ọrun já silẹ, awọn agbara ọrun li ao sì mì-titi. Nigbanà ni àmi Ọmọ-enia yio hàn li ọrun ; nigbanà ni gbogbo orilẹ-ède aiye yio sọkún, nwọn o sì ri Ọmọ-enia, ti mbọ̀ lârin awọ-sanma oju ọrun ti on ti agbara nla ati ọlá nla. On yio sì rán awọn Angẹli rẹ pẹlu fère ati ohùn ìpe nla, nwọn yio sì kó gbogbo awọn ayanfẹ rẹ lati ori igun mẹrẹrin aiye jọ, lati ikangun ọrun kini lọ de ekeji. Ẹ kọ́ owe yi ti a yọ jade ninu igi ọpọtọ. Nigbati ẹká rẹ ba tún ṣọmudun, ti o ba sì ru ewé, ẹnyin mọ̀ pe ìgba ẹ̀rùn sùnmọ́ etile. Bẹ gẹgẹ ni, nigbati ẹnyin ba ri gbogbo nkan wọnyi, ki ẹ mọ̀ pe Ọmọ-enia sùnmọ́ etile, ani o wà lẹhin ilẹkun. Lôtọ ni mo wí fun nyin pe, iran yi kì yio rekọja titi a o fi mu gbogbo nkan wọnyi ṣẹ. Ọrun on aiye yio rekọja, ṣugbọn ọ̀rọ mi kì yio rekọja.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, ṣojurere si èbẹ wa, ki o sì tẹwọgbà ẹbọ ati adura awọn ẹnia rẹ; yí ọkàn gbogbo wa pada si Ọ, pe nipa bibọ kuro ninu ifẹ ohun ti aiye yi, ki awa lè mà ṣe aferi kìki ohun ini ọrun nikan; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifunni, ki sakramenti mimọ yi ti awa ti gbà, ki o lè mu ohunkohun ti o bàjẹ ninu ọkàn wa larada nipa agbara imularada rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ IGBEGOKE ỌRUN TI MARIA WUNDIA MIMỌ

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ jẹ ki gbogbo wa ki o mà yọ ninu Oluwa li ojọ́ ọdún mimọ́ yi, ti awa nṣe fun ọlá Maria Wundia alabukúnfun, nitori Igbegoke ọrun ẹniti awọn Angẹli nyọ̀, ti nwọn sì nfi ohùn kan yin Ọmọ Ọlọrun. *Ps.* Ọkàn mi nsòrọ rere jade; ogo Ọba li emi sì nkọ orin yi si Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, dari èṣẹ awọn iranṣẹ rẹ jì wọn, ki awa ti kò lè wù ọ nipa iṣẹ

ara wa tikalawa, ki o lè là nipa ẹbẹ Iyá Ọmọ rẹ, Oluwa wa Jesu-Kristi, ẹniti o wà, ti o sì njọba pẹlu rẹ ninu iṣokan Ẹmi-Mimọ, lai Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (Ekles. 24).

Ninu ohunkohun li emi nwá ibi isimi, emi o sì mâ gbé inu ilẹ iní ti Oluwa. Nigbanâ ni Ẹlẹdá ohun gbogbo ba mi sòrọ, o sì fi ifẹ inu rẹ hàn mi; ẹniti o dá mi si ngbé inu ibugbé mimọ mi, o sì wí fun mi pe: mâ gbé inu Jakọbu; ki Israeli sì jẹ ilẹ iní rẹ, ki iwọ ki o sì fi ẹsẹ rẹ mulẹ ninu awọn ayanfẹ mi. Bayi ni a ti fi idi mi kalẹ ni Sioni mo sì ri ibi isimi mi ninu ilú mimọ nâ, emi sì njọba ni Jerusalemu. Mo ti fi ẹsẹ mi mulẹ ninu orilẹ-ède nâ ti Oluwa bọláfun, awọn enia eyiti Ọlọrun mi ti yàn li ipín rẹ, ibugbé mi sì wà ninu ijọ gbogbo awọn Enia Mimọ. Mo ti hù soke bi igi sedari ni Libanoni, ati bi igi sipresi lori òke Sioni. Mo ti gbà bi igi ọpẹ ni Kadesi ati bi eweko rose ni Jeriko. Mo ti hù soke bi igi olifi ti o o lẹwa ni pápa, ati bi igi ẹgun ti a gbìn li opópo ọna leti omi; emi ti rán ôrun didùn jade bi ti epọ igi kanẹla ati bi ti ikunra oniyebiye julọ; emi ti rán ôrun didùn jade bi ti ojia ti o dara julọ.

Graduali. Nitori otitọ, ìwa tutù, ati ododo rẹ, ni ọwọ ọtún rẹ yio mu ọ ṣe iṣẹ iyanu nlanla. Fetisi, ọmọbirin mi, ki o sì wò, ki o sì dẹ etí rẹ silẹ, nitoriti ẹwa rẹ wù Ọba gidigidi. Alleluia, alleluia. A gbé Maria goke ọrun; ogun awọn Angẹli sì nyọ nitorinâ. Alleluia.

Ihin rere (Luk. x, 38).

Nigbanà ni Jesu wọ iletò kan lọ, obirin kan ti a npè ni Marta sì gbà a sile rẹ. O sì ni arabirin kan ti a npè ni Maria, ti o joko lẹba ẹsẹ Jesu, ti o sì ngbọ́ ọ̀rọ rẹ. Ṣugbọn ọwọ́ Marta dí pupọ nipa pipèse ohunkohun silẹ lati gbà a bi o ti yẹ, o sì tọ Jesu wá, o ni : Oluwa, iwọ kò ha ṣùsi i ti arabirin mi ti o fi mi silẹ lati mâ nikan ṣiṣẹ? Nitorinà wí fun u ki o ràn mi lọwọ. Jesu dahùn, o sì wí fun u pe : Marta, Marta, iwọ nṣe aniyàn ati lâla nitori ohun pupọ ; ṣugbọn ohun nikan li a kò lè ṣe alaini. Maria ti yàn ipa ọ̀na rere nâ, ti a kò lè gbà lọwọ́ rẹ.

Ifitọrẹ. A ti gbé Maria goke ọrun ; awọn Angẹli sì nyọ̀ nitorinâ, nwọn sì nfi ibukún ati iyìn fun Oluwa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki adura Iyá Ọlọrun ki o lè ràn awọn enia rẹ lọwọ́ ; bi a sì ti mọ̀ pe O ti jade ninu aiye yi lati mu ofin ẹran ara ṣẹ, jẹ ki a lè mọ̀ agbara ẹ̀bẹ rẹ̀ fun wa lọdọ́ rẹ li ogo ọrun : nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Maria ti yàn ipa ọ̀na rere nâ, ti a kò lè gbà lọwọ́ rẹ̀ lai.

Adura lẹhin komunioni.

Bi awa ti jẹ alabapín ninu onjẹ rẹ ọrun, awa mbẹ̀bẹ lọdọ́ ânu rẹ, Oluwa Ọlọrun wa, fifunni,

ki awa ti mbolá fun Igbegoke ọrun ti Iyá Olọrun ki o lè lá nipa èbẹ rẹ̀ kuro lọwọ́ gbogbo ibi ti nfẹ́ de si wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ JOAKIMU MIMỌ, BABA WUNDIA MIMỌ

Li ijọ́ ọsẹ ti o tẹle ọjọ́ Igbegoke ọrun ti Maria mimọ́

Ipilẹsẹ ti Misa. O ti fún olun iní rẹ̀ ká fun awọn talakà, ododo rẹ̀ sì duro lailai; agbara rẹ̀ li ao sì gbé ga li ogo. *Ps.* Alabukún fun li ẹniti o bẹ̀ru Oluwa, ti inu rẹ̀ dùn jọjọ lati pa ofin rẹ̀ mọ́. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Olọrun, Iwọ ti o ti yàn Joakimu mimọ́ ni baba ti Iyá Ọmọ rẹ̀ ṣiwaju gbogbo awọn Ènia mimọ́ rẹ̀, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ̀, fifunni, ki awa ti mbolafun ọjọ́ ọdún mimọ́ rẹ̀, ki o lè mâ ri âbo rẹ̀ gbà nigbagbo; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura 2° ti Ijọ́ ọsẹ; 3° ti Igbegoke ọrun ti Maria mimọ́.

Epistoli (Ekles. xxxi. 8).

Alabukún fun li ọkọnri nâ ti a ri laini àbukùn, ti kò sì lepa wura, bẹ̀ni ti kò sì gbẹkẹle ówo tabi iṣura. Tani oluwa rẹ̀, ao sì yìn i?

Nitoriti o ti ṣe ohun iyanu niwọn ọjọ aiye rẹ. A ti fi wura dán a wò, a sì ri i ni pipé, ogo rẹ kì yio sì nipẹkun. On ti lè dẹṣẹ, ṣugbọn kò dẹṣẹ; on ti lè ṣe ohun buburu, ṣugbọn kò ṣe wọn, nitorinâ a ti fi idi ohun iní rẹ kalẹ ninu Oluwa, gbogbo ijọ awọn Enia mimọ ni yio sì mâ rohìn ôre-âyu rẹ ti o ti ṣe.

Graduali. O ti fún ohun iní rẹ ká fun awọn talakà, ododo rẹ sì duro lailai. Irú-ọmọ rẹ yio lagbara li aiye; iran awọn olododo li a o bukún fun. Alleluia, alleluia. Iwọ Joakimu, ọkọ mimọ ti Anna, baba Wundia ti o logo, ràn awọn ọmọ-ọdọ rẹ lọwọ ki nwọn ki o lè ri igbalà ainipẹkun gbà. Alleluia..

Ihin rere (Mat. 1.)

Iwe iran Jesu-Kristi, ọmọ Dafidi, ọmọ Abrahamu, Abrahamu bí Isaaki, Isaaki bí Jakọbu, Jakọbu bí Juda ati awọn arakọnri rẹ, Juda bí Faresi ati Sara lati ọdọ Tamari wá, Faresi bí Esroni, Esroni bí Aramu, Aramu bí Aminadabu, Aminadabu bí Naasoni, Naasoni bí Salmoni, Salmoni bí Boosi lati ọdọ Rahabu wá, Boosi bí Obedi lati ọdọ Rutu wá, Obedi bí Jesse, Jesse sì bí Dafidi, ọba, Dafidi, ọba, bí Salmoni lati ọdọ ẹniti o ti nṣe aya Uria wá. Salmoni bí Roboamu, Roboamu bí Abia, Abia bí Asa, Asa bí Josafati, Josafati bí Joramu, Joramu bí Osia, Osia bí Joatamu, Joatamu bí Akasi, Akasi bí Esekiasi, Esekiasi bí Manasse, Manasse bí Amoni, Amoni bí Josia, Josia bí Jekonia, ati awọn arakọnri rẹ, li akokò ti a fi kó wọn lọ si Babiloni. Lẹhin igbati a fi kó wọn lọ si Babi-

loni ni Jekonia bí Salatieli, Salatieli bí Sorobabeli, Sorobabeli bí Abindu, Abindu bí Eliasimu, Eliasimu bí Asori, Asori bí Sadoki, Sadoki bí Akimu, Akimu bí Elindu, Elindu bí Eleasaru, Eleasaru bí Matani, Matani bí Jakọbu, Jakọbu sì bí Josefu, ọkọ Maria, lati ọdọ ẹniti a bi Jesu, ti a npè ni Kristi.

Ifitọrẹ. Oluwa, iwọ ti fi ogo ati ọlá dé e lade; iwọ sì fi i jẹ olori iṣẹ ọwọ́ rẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Ọlọrun alânu julọ, fi ojurere gbà ẹbọ yi ti a ru si Ọlá nla rẹ fun ogo patriarki Joakimu mimọ́, baba Maria Wundia, pe nipa ẹbẹ rẹ̀, ti aya rẹ̀, ati ti ọmọbirin rẹ̀ alabukún fun ki a lè ri idariji ẹ̀ṣẹ̀ wa gbà, ati alafia ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura 2e; ati 3e, bi t'iwaju.

Preface ti Maria Wundia.

Komunioni. Eyi ni iranṣẹ olõtọ ati ọlọgbọ́n nâ, ti oluwa rẹ̀ fi jẹ olori agbo ile rẹ̀, lati mâ fi ìwọn onjẹ wọn fun wọn li akokò.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, pe nipa sakramenti mimọ́ yi ti awa ti gbà, ati nipa iranlọwọ́ itoye ati ẹbẹ Joakimu mimọ́, baba Iyá Ọmọ rẹ ayanfẹ Oluwa wa Jesu-Kristi, ki awa ki o lè yẹ lati jẹ alabapín ninu ôre-ọfẹ rẹ li aiye yi, ati ninu ogo ti kò nipẹkun li aiye ti mbọ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura 2e; ati 3e, bi t'iwaju.

ỌJỌ TI GBOGBO AWỌN ENIA MIMỌ

Ojọ́ kini ti Novemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ jẹ ki a mâ yọ̀ ninu Oluwa li ojọ́ ọdún mimọ́ yi, ti a nṣe fun ogo gbogbo awọn enia mimọ́; nitori ọdún mimọ́ ẹniti awọn Angẹli nyọ̀, ti nwọn sì nyìn Ọmọ Ọlọrun logo. *Ps.* Ẹ mâ yọ̀ ninu Oluwa, ẹnyin olododo; o yẹ fun awọn olododo ọkàn nikan lati mâ kọrin iyìn rẹ̀. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o fi ôre-ọ̀fẹ fun wa lati bọlá fun awọn itoye gbogbo awọn Enia mimọ́ rẹ pọ̀ ninu ọdún mimọ́ yi awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, pe bi awa ti ni ọ̀pọ̀lọpọ ẹ̀lẹbẹ ti ngbadura fun wa to bayi, bẹ̀ gẹgẹ ni ki o lè wù Ọ lati dà iṣura ânu rẹ si wa lori lọpọ̀lọpọ̀; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ifihàn VII, 2).

Li ojọ́ wọnyi li emi Johanu ri Angẹli miran kan, ti o nti ìha ìla ôrùn goke wá, ti o sì ní àmi Ọlọrun alâye lọwọ́; o sì kigbe li ohùn rara si awọn Angẹli mẹrin, ti a fi aṣẹ fun lati pa ilẹ aiye ati okun lara, wipe: Ẹ máṣe pa ilẹ aiye, tabi okun, tabi igi lara titi awa o fi sàmi si awọn iranṣẹ Ọlọrun wa niwaju ori wọn. Mo sì gbọ́ pe iye awọn ẹniti a sàmi si jẹ ọkẹ meje o le ẹgbaji lati inu gbogbo awọn

èya awọn ọmọ Israeli wá. Ninu èya Juda a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Rubeni a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Gadi a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Aseri a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Neftali a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Nanasse, a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Simeoni a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Lefi a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Isakari a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Sabuloni a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Josefu a sàmi si ẹgbâfa. Ninu èya Benfamini a sàmi si ẹgbâfa. Lẹhin eyi mo ri ọpọlọpọ enia ti ẹnikẹni kò lè kaye wọn, lati inu gbogbo orilẹ-ède, gbogbo èya, gbogbo enia, ati gbogbo ède wá. Nwọn duro niwaju itẹ ati Ọdọ-agutan ni, a wọ wọn li aṣọ igunwa funfun, nwọn sì ní mariwò li ọwọ wọn (eyiti o jasi àmi iṣẹgun), nwọn sì kigbe li ohùn rara, wipe : Ogo ni fun Olọrun ti o joko lori itẹ, ati fun Ọdọ-agutan nitori igbalà wa. Gbogbo awọn Angẹli sì duro yí itẹ nà ká, ati yí awọn alàgba ati awọn ẹdá alâye mẹrin nà ká, nwọn sì wolẹ niwaju itẹ ni idojubolẹ, nwọn sì nsìn Olọrun, wipe : Amin. Ibukún, ogo, ọgbọn, ọpẹ, ọlá, agbara ati ipá wà fun Olọrun wa lai ati lailai. Amin.

Graduali. Ẹ bèru Oluwa, enyin enia mimọ rẹ, nitoriti kò si aini fun awọn ti o bèru rẹ. Awọn ti nwá Oluwa kì yio ṣe alaini ohun ti o dara. Alleluia, alleluia. Ẹ wá sọdọ mi, gbogbo enyin ti nṣiṣẹ, ti a sì di ẹrù wuwo le lori, emi o fun nyin li itura. Alleluia.

Ihin rere (Mat. v, 1).

Nigbanâ, bi Jesu ti ri ọpọ enia, o gùn ori

òke lọ, nigbati o sì joko, awọn ọmọ rẹ tọ ọ wá ; o sì yà ẹnu rẹ, o sì nkọ́ wọn, wipe : Alabukún fun li awọn otoṣi li ẹmí, nitoriti nwọn ni ijọba ọrun. Alabukún fun li awọn olọkàn tutù, nitoriti nwọn o jogún aiye. Alabukún fun li awọn ẹniti nsọkún, nitoriti ao tù wọn ninu. Alabukún fun li awọn ẹniti ebi npa, ti ongbẹ sì ngbẹ fun ododo, nitoriti ao tẹ́ wọn lọrùn. Alabukún fun li awọn alânu, nitoriti nwọn o ri ânu gbà. Alabukún fun li awọn oninu funfun, nitoriti nwọn o ri Ọlọrun. Alabukún fun li awọn onilàja, nitoriti ọmọ Ọlọrun li ao mà pè wọn. Alabukún fun li awọn ẹniti a nṣe inunibini si nitoriti ododo, nitoriti nwọn ni ijọba ọrun. Alabukún fun ni ẹnyin, nigbati, awọn enia ba nkẹgàn nyin, ti nwọn ba nṣe inunibini si nyin, ti nwọn ba sì nti eké sòrọ buburu gbogbo si nyin nitori mi. Ẹ mà yọ̀, ki ẹnyin ki o sì mà yọ̀ ayọ̀ nla, nitori ère nyin pọ̀ li ọrun.

Ifitọrẹ. Okàn awọn olododo mbẹ li ọwọ́ Ọlọrun, a kì yio da wọn loró mọ́, bẹ̀ni a kì yio pọ́n wọn loju mọ́. Loju awọn okuyé nwọn dabi ẹnipe nwọn kú, ṣugbọn nwọn wà li alafia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa ru awọn ẹbun ifokànsìn wa si Ọ, jẹ ki nwọn lè jẹ atẹwọgbà fun Ọ nitori ogo gbogbo awọn Enia mimọ́ rẹ, ati nipa ânu rẹ ki nwọn sì lè ṣe anfani fun igbalà wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Alabukún fun li awọn oninu

funfun, nitoriti nwọn o ri Ọlọrun ; alabukún fun li awọn onilàja, nitoriti ọmọ Ọlọrun li a o mâ pè wọn ; alabukún fun li awọn ẹniti a nṣe inunibini si nitori ododo, nitoriti nwọn ni ijọba ọrun.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, jẹ ki awọn enia olôtọ rẹ mâ fi ayọ bọlá fun gbogbo awọn Enia mimọ rẹ nigbagbogbo, ati nipa ẹbẹ wọn ki a sì lè dâbobo wa titilọ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌKÀN MIMỌ JULỌ TI MARIA WUNDIA

Alâbo awọn Kristiani ti sakâni ilẹ Yoruba.

Ijọ ọsẹ lẹhin ọjọ kejọ ti Igbegoke ọrun ti Maria mimọ.

Ipilẹsẹ ti Misa. Gbogbo ogo ọmọbirin Ọba ti inu ọkàn rẹ wá lârin oko eti aṣọ wura, ati onirûrun ohun ọṣọ ti a fi yí i ká ; awọn wundia li ao mu tọ Ọba wá lẹhin rẹ ; ao sì mu awọn aladugbò rẹ tọ Ọ wá, Oluwa. *Ps.* Ọkàn mi nsọ òro rere jade ; ogo Ọba li emi sì nkọ orin yi si. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, Iwọ ti o

pèse ibugbe ti o yẹ silẹ fun Ẹmi-Mimọ ninu Ọkàn Maria Wundia alabukún fun. nipa ànu rẹ ifunni, ki awa ti nfi ifọkànsìn bọlá fun ọjọ ọdún mimọ ti Ọkàn rẹ mimọ julọ ki o lè mâ wà gẹgẹ bi Ọkàn rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Orin Salom. VIII, 7).

Gbé mi le àiya rẹ bi èdidi, bi èdidi le apa rẹ ; nitori ifẹ lagbara bi ikú, ijowú sì le bi isà okú ; fitila rẹ dabi fitila iná ati ọwọ-iná. Omi pupọ kò lè paná ifẹni, bẹni kikún omi kò lè gbà a lọ : Bi enia ba fi gbogbo ọrọ ile rẹ fun ifẹ, a ki yio kà a si nkan.

Graduali. Ohunkohun ti iṣe-èri kì iwọ inu rẹ ; nitori on ni imudaṣaṣa ti imọlẹ aiyeraiye, digi alaini abukùn ti Ọlá nla Ọlọrun, ati aworan inu rere rẹ. Emi jẹ ti olufẹ mi, olufẹ mi sì jẹ ti emi, nitori o njẹ làrin itanná lili. Alleluia, alleluia. Ọkàn mi nyìn Oluwa logo, ẹmí mi sì nyọ si Ọlọrun Olugbala mi. Alleluia.

Ihin rere (Luk. II, 48).

Nigbanâ ni Iyá Jesu wí fun u pe : Ọmọ mi, èṣe ti iwọ fi nṣe bẹ fun wa? Sawò o, baba rẹ ati emi ti nfi ibanujẹ wá Ọ kiri. O sì dahùn wí fun wọn pe : Enyin kò ha mọ pe emi kò lè ṣalaima ṣe ohun ti iṣe ti Baba mi? Sugbọn ọrọ ti o sọ kò yé wọn. Lehinnâ o ba wọn sọkalẹ lọ, o sì wá si Nazareti ; o sì tẹriba fun wọn. Iyá rẹ sì pa gbogbo nkan wọnyi mọ ninu ọkàn rẹ.

Ifitọrẹ. Nitori iwọ ti fi igboiya ọkọnri ṣe, iwọ sì mu ara rẹ lọkànle ; nitorinà ni ọwọ́ Oluwa ṣe mu ọ lagbara, alabukún fun ni iwọ yio sì mà jẹ ti:ilai.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa ti nru ọdọ-agutan alaini abukùn ni lẹbọ si Ọlá nla rẹ, mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki a daná ifẹ́ mimọ́ kannà sinu ọkàn wa, ti o jó ọkàn Maria Wundia alabukún fun li ọna alailèsọ jade ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Emi joko labẹ ojiji ẹniti mi fẹ́, eso rẹ̀ sì dùnmọ mi li ẹnu.

Adura lẹhin komunioni.

Awa ti o ri ẹbun mimọ́ rẹ gbà, nfi itara gbigbona bèbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, pe nipasẹ ẹbẹ Maria Wundia alabukún fun, ọdún mimọ́ ti Ọkàn mimọ́ julọ ẹnitu awa mbọlàfun, ki a lè bọ́ kuro lọwọ́ ewu ti isisiyi, ki o sì fi ayọ̀ aiye ti kò nipẹkun fun wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

ỌJỌ IGBÉSOKE TI AGBELEBU MIMỌ

Li ọjọ́ 14e ti oṣù septemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. O yẹ ki awa ki o mâ ṣogo ninu Agbelebu Jesu-Kristi Oluwa wa ; ẹniti

iṣe olorisun igbalà wa, ìyẹ ati ajinde wa ; nipasẹ ẹniti a ti gbà wa là, ti a sì ti dá wa nidè. *Ps.* Ki Olọrun ki o ṣãnu fun wa, ki o sì bukún fun wa ; ki o mu imọlẹ oju rẹ̀ hàn si wa, ki o sì mã ṣãnu fun wa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun, Iwọ ti o run wa li ohun ayọ̀ titun lọdọdún ojọ́ oni nipasẹ ọdún mimọ́ ti igbésoke Agbelebu mimọ́, tifun wa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, pe lẹhin ìgbati a ti mọ̀ ọ̀rọ ijinlẹ rẹ̀ li aiye yi, ki a lè yẹ lati ri eso iràpada rẹ̀ gbà li ọrun rere ; nipasẹ Jesu-Kristi,Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Filipi II, 5).

O ri gẹgẹ bi ti misa li ijọ́ ọsẹ ti Mariwò.

(wò apa 158).

Graduali. Kristi tẹriba titidi oju ikú, ani ikú lori agbelebu. Nitorinà ni Olọrun ti ṣe gbé e ga gidigidi, ti o sì ti fi orukọ kan fun u, ti o bori gbogbo orukọ. Alleluia, alleluia. Igi olufẹ, iṣó mimọ́, enyin ti rù ẹrù iyebiye ; agbelebu, iwọ nikan li o yẹ lati gbé Oluwa ati Ọba ọrun. Alleluia.

Ihin rere (Joh XII, 31).

Nigbanà ni Jesu wí fun ijọ awọn Ju pe : Nigbayi li a ṣe idajọ aiye. Nigbayi li a o lé onọ-alade aiye yi jade, ati emi, nigbati a ba gbé mi soke lati ilẹ, emi o fà gbogbo enia sodọ mi. O wí eyi lati ṣapẹrẹ irú ikú ti On o kú.

Awọn enia da a lohùn wipe : Awa gbọ́ ninu ofin pe Kristi wà lailai. Bawo ni iwọ sì ti ṣe wipe : A kò lè ṣaimágbé Ọmọ-enia soke? Tani ṣe Ọmọ-enia yi? Jesu sì da wọn lohùn wipe : Niwọn igba diẹ si i ni imọlẹ wà lodọ nyin. Ẹ mâ rìn nigbati ẹnyin ni imọlẹ, ki òkunkun ki o máṣe bá nyin lojiji, nitori ẹniti o ba nrìn li òkunkun kò mọ ibiti on gbé nlọ, ki ẹnyin ki o lè jẹ ọmọ imọlẹ.

Ifitọrẹ. Oluwa, dàbobo awọn enia rẹ nipa àmi agbelebu mimọ́ kuro ninu arekereke gbogbo awọn ọtá wọn, ki isìn wa ki o lè jẹ atẹwọgbà fun ọ, ki ẹbọ wa ki o sì lè di yiyẹ lati ru si ọ.

Adura ti a hà jẹjẹ.

Bi awa ti nmura lati fi ara ati èjẹ Jesu-Kristi Oluwa wa bọ́ ara wa, ẹniti o sọ asia agbelebu di mimọ́, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, Oluwa Olọrun wa, fifunni pe bi a ti sọ wa di yiyẹ lati bọlá fun agbelebu iyebiye nâ, bẹ gẹgẹ ni ki a lè mâ jẹ ninu eso ogo igbalà rẹ titilai; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Oluwa Olọrun wa, nipa àmi agbelebu gbà wa là kuro lọwọ́ gbogbo awọn ọtá wa.

Adura lẹhin komunioni.

Ràn wa lọwọ́, Oluwa Olọrun wa, ki o sì mâ dàbobo wa titilai nipa âbo agbelebu mimọ́ nâ, ti awa ntí ayọ́ ri pe a mbọlá fun bi o ti yẹ; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ROSARIO MIMỌ JULỌ TI MARIA WUNDIA ALABUKUN FUN

Ijọ́ ọsẹ kini ti oṣù Oktoberi

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ jẹ ki gbogbo wa ki o mà yọ̀ ninu Oluwa li ọjọ́ ọdún mimọ́ yi, ti a nṣe fun ọlá Maria Wundia alabukún fun, nitori ọdún mimọ́ eniti awọn Angẹli nyọ̀, ti nwọn sì nyìn Ọmọ Ọlọrun logo. *Ps.* Ọkàn mi nsọ òrọ rere jade, ogo Ọba li emi sì nkọ orin yi si; Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, eniti Ọmọ bibí rẹ̀ nikanṣoṣo ti fi aiye, ikú ati ajinde rẹ̀ gbà ère igbalà ainipẹkun fun wa, fifunni, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, pe ki a lè mà ṣe aṣàro ninu awọn òrọ ijinlẹ wọnyi ninu Rosario mimọ́ julọ ti Maria Wundia alabukún fun, ki a sì lè mâ tọpasẹ ohun ti o wà ninu wọn, ki a sì lè ri ohun nà gbà, ti nwọn ṣe ileri; nipasẹ Jesu-Kristi kanna Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Owé VIII, 22).

Oluwa ti ní mi lọdọ rẹ̀ ni ipilẹṣẹ ìwa rẹ̀, ki on to dá ohun kan. A ti yàn mi lati aiyeraiye, ati lati ipilẹṣẹ wá, ki a to dá ilẹ aiye. Awọn ibú okun kò ti isi, nigbati a ti bi mi. Njẹ nisisiyi ẹ fetisi mi, ẹnyin ọmọ mi, alabukún fun li awọn ti o tẹle ọ̀na mi. Ẹ gbọ́ ẹkọ́ mi, ki ẹnyin ki o sì gbọ́n, ki ẹ má sì ṣe kọ̀ ọ silẹ. Alabukún fun li eniti o gbọ́ ti emi, ti o sì nṣọ́ ẹnu-ọ̀na ile mi lojojumọ ti o sì nduro tì òpó ẹnu

ilẹkun mi. Nitoripe ẹniti o ri mi, o ri ìye, yio sì ri igbalà gbà lọwọ Oluwa.

Graduali. Nitori otitọ, ìwa tutù ati ododo rẹ, ni ọwọ ọtún rẹ yio mu ọ sẹ ohun iyanu nlanla. Fetisi, ọmọbirin mi, ki o sì ṣijuwò, ki o sì dẹ etí rẹ silẹ : nitoriti ẹwa rẹ wù Ọba gidigidi. Alleluia, alleluia. Ọdún mimọ ti Maria Wundia ologo ni, ẹniti a bí lati inu iran Abrahamu, ti o sì jade lati inu ẹya Juda, ati idile olokiki ti ọba Dafidi wá. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 1, 26).

Nigbanà ni a rán Angẹli Gabrieli lati ọdọ Ọlọrun lọ si ilú kan ni Galili, ti a npè ni Nasareti, si Wundia kan ti a fẹ fun ọkọnri kan, ti a npè ni Josefu, ti idile Dafidi ; orukọ Wundia nâ a sì mâ jẹ Maria. Angẹli nâ sì tọ ọ wá, o sì wí fun u pe : Mo kí ọ, iwọ ti o kún fun ôreọfẹ, Oluwa mbẹ pẹlu rẹ ; alabukún fun ni iwọ ninu awọn obirin ! Nigbati o gbọ nkan wọnyi, ara rẹ kò balẹ li ọrọ rẹ, o sì rò ninu ara rẹ pe irú ikí wo li eyi lè jẹ. Angẹli nâ sì wí fun u pe : Máṣe bẹru, Maria, nitori iwọ ti ri ojurere lodọ Ọlọrun. Sá kiyesi i, iwọ o lóyun ninu rẹ, iwọ o sì bí ọmọkọnri, iwọ o sì pè orukọ rẹ ni Jesu ; on yio tobi, ao sì mâ pè e ni Ọmọ Ọgá-ogo. Oluwa Ọlọrun yio sì fi itẹ Dafidi baba rẹ fun u : On yio sì jọba lori ile Jakọbu titilai ; ijọba rẹ kì yio sì nipẹkun. Nigbanà ni Maria wí fun Angẹli nâ pe : Bawo ni yio ha ṣe ri bẹ, nigbati emi kò mọ ọkọnri ? Angẹli nâ sì da a lohùn wipe : Ẹmi-Mimọ yio wá sori rẹ, agbara Ọgá-ogo yio sì ṣijibò ọ. Nitorinà ni eso

mimọ́ ti ao ti inu rẹ bí, Ọmọ Ọlọrun li ao mà pè e. Sì kiyesi i, Elisabeti, ará rẹ, on pẹlu lóyun ọmọkọnrin li ogbologbo rẹ̀; osù kẹfa sì li eyi fun ẹniti a npè ni àgan, nitori kò si ohun kan ti Ọlọrun kò lè ṣe. Lẹhin eyi Maria wi fun u pe: Wò ọmọ-ọdọ́ birin ti Oluwa, ki o ri fun mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ.

Ifitọrẹ. Ninu mi ni gbogbo ôre-ọfẹ ti ọ̀na ati ti otitọ; ninu mi ni gbogbo ireti ti iye ati ti ìwa rere, emi sì seso gẹgẹ bi itanná rose ti a gbìn leti odò.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ṣọ wa di yiyẹ lati ru ẹbọ yi si Ọ, ki o si tifunni, pe nipa awọn ọ̀rọ ijinlẹ ti Rosario mimọ́ julọ, ki a lè bọlá fun aiye, ijiyà ati ogo ti Ọmọ bibí rẹ nikanṣoṣo, tobẹ̀ ti a lè fi ṣọ wa di yiyẹ fun awọn ileri rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi kannà Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹ yọ itanná jade gẹgẹ bi lili, ki ẹ sì rán ôrùn didùn jade, ki ẹ sì ruwé daradara; ẹ mà kọ orin iyìn, ki ẹ sì fi ibukún fun Oluwa ninu iṣẹ rẹ̀.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, jẹ ki a lè ràn wa lọwọ́ nipa adura ti Iyá rẹ mimọ́ julọ. Rosario ẹniti a nṣe ọdún mimọ́ rẹ̀; ki awa ki o lè mọ̀ agbara ti awọn ọ̀rọ ijinlẹ rẹ ti awa mbọlá fun, ki sakramenti mimọ́ rẹ ti awa ti gbà ki o sì lè seso ninu wa: Iwọ ti o wà, ti o si njọba pẹlu Ọlọrun Baba ninu isọkan Ẹmi-Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

TE DEUM

Te Deum laudamus, te Dominum confitemur.	A yìn Ọ, Ọlọrun, a sì jẹwọ rẹ li Oluwa.
Te æternum Patrem, omnis terra veneratur.	Baba ainipẹkun, aiye gbogbo bọwọ fun Ọ.
Tibi omnes Angeli, tibi cœli et universæ potestates.	Gbogbo Angẹli, ọrun, ati awọn agbara gbogbo.
Tibi Cherubim et Seraphim incessabili voce proclamant.	Awọn Kerubimu on Serafimu, li ohùn aisimi, nwipe
Sanctus, sanctus, sanctus, Dominus, Deus sabaoth.	Mimọ, Mimọ, Mimọ, l'Oluwa, Ọlọrun, awọn ọmọ-ogun
Pleni sunt cœli et terra, majestatis gloriæ tuæ.	Ọrun ati aiye kún fun ọlá ogo rẹ.
Te gloriosus apostolorum chorus.	Iṣọkán-ohùn ologo ti awọn apostoli.
Te prophetarum laudabilis numerus.	Ọwọ awọn woli oniyìn.
Te martyrum candidatus laudat exercitus.	Ogun awọn Martiri ọlokiki jumọ nyìn Ọ.
Te per orbem terrarum sancta confitetur Ecclesia.	Ni yiyí aiye ká, Eklesia mimọ jẹwọ rẹ.
Patrem, immensæ majestatis.	Baba, ọlọla ainipẹkun ni Ọ.
Venerandum tuum verum et unicum Filium.	Ati Ọmọ tôtọ ati nikan-ṣoṣo tirẹ.

Sanctum quoque, Paraclitum Spiritum.
Tu rex gloriæ, Christe.
Tu patris, sempiternus es Filius.
Tu ad liberandum suscepturus hominem, non horruisti Virginis uterum.
Tu, devicto mortis aculeo, aperuisti credentibus regna cœlorum
Tu ad dexteram Dei sedes in gloria Patris
Judex crederis esse venturus.
Te ergo, quæsumus, tuis famulis subveni, quos pretioso sanguine redemisti.
Æterna fac cum sanctis tuis in gloria numerari.
Salvum fac populum tuum, Domine, et et benedic hœreditati tuæ.
Et rege eos, et extolle illos usque in æternum.

Per singulos dies, benedicimus te.

Ati Ẹmi Mimọ́ olutunu rẹ
Iwọ l'ọba ogo, Kristi!
Iwọ l'Ọmọ ainopin ti Baba.
Nigbati o fẹ́ rà araiye pada, Iwọ kì bẹ̀ru inu ti Wundia.

Ni ṣiṣẹgun oró ikú tán, Iwọ ti ṣi ijọba ọrun silẹ fun awọn onigbagbọ́.
Li ọwọ́ ọtún Ọlọrun l'o wà, li ogo Baba.
A gbagbọ́ pe Iwọ o pada wá, ba enia wijọ.
L'ọdọ rẹ l'a mbẹ̀bẹ, ran awọn ọmọ-ọdọ rẹ lọwọ́, eniti o rà lẹjẹ rẹ iyebiye.
Mu kí a kà wọn pelu awọn Angẹli l'ogo ọrun rere.
Gbà awọn enia rẹ là, Oluwa, ki o si bukúnfun ohun itori tirẹ.
Ki ọwọ́ rẹ ma dari wọn, k'o si gbé wọn ga titi de aiye ainipẹkun.
Lojojumọ l'a bukúnfun Ọ.

Et laudamus nomen tuum in sæculum et in sæculum sæculi.	A sì nyìn orukọ rẹ nisisiyi, ati titi lọ.
Dignare, Domine, die isto sine, peccato nos custodire,	Oluwa, gbọ́ tiwa l'oni yi, k'o sì pa wa mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀kẹ̀ṣẹ.
Miserere nostri, Domine, miserere nostri.	Ṣânu fun wa, Oluwa, ṣânu fun wa.
Fiat misericordia tua, Domine, super nos quemadmodum speravimus in te.	Ki ânu rẹ k'o wà lori wa, Oluwa, nìwọn t'awa ni igbẹ̀kẹ̀le si Ọ.
In te, Domine, speravit; non confundar in æternum.	Mo gbẹ̀kẹ̀le Ọ, Oluwa, oju kì yio sì tì mi lai.

STABAT MATER

1	1
Stabat mater dolorosa.	Li omije, l'ibanujẹ.
Juxta crucem lacrymosa.	Iyá duro l'ẹ̀ṣẹ̀ igi,
Dum pendebat Filius.	Nibit'Ọmọ rẹ̀ njiya.
2	2
Cujus animam gementem.	Lẹhin imiẹdun t'o pọ̀.
Contristatam, et dolentem.	Lẹhin ainitunu rara.
Pertransivit gladius.	Ida oró gún u l'ọkàn.
3	3
O quam tristis et afflicta	Olubukún Iyá Jesu.
Fuit illa benedicta.	Ti ni ọkàn t'o baje to.
Mater Unigeniti!	Fun onirûru irà!

4	4
Quæ mœrebat, et dolebat.	Kò si simi kò s'alafia.
Pia Mater dum videbat	Fun Iyá olinure jù.
Nati pœnas inclyti.	T'o nrì Ọmọ l'irora.
5	5
Quis est homo qui non fleret.	Enia wo ni kì yio sọkun.
Matrem Christi si videret.	Ti o ba ri Iyá Kristi.
In tanto suplicio?	Ninu ipọnju nla yi ?
6	6
Quis non posset contristari	Ọkàn tani kì ba bajẹ.
Christi Matrem comtemplari.	Ni wiwò Iyá t'o ṣ'ọfọ.
Dolentem cum Filio!	T'o ba Ọmọ rẹ pinyà !
7	7
Pro peccati suæ gentis	O ri pe Jesu nwahala.
Vidit Jesum in tormentis.	Nkerora li ọna gbogbo
Et flagellis subditum.	Fun ẹṣẹ ará tirẹ.
8	8
Vidit suum dulcem natum.	O ri Ọmọ rẹ Olufẹ.
Morientem, desolatum	T'o nkú lọ, t'a sì kọ silẹ.
Dum emisit spiritum.	Njọwọ́ ẹmi rẹ l'ọwọ́.
9	9
Eia, Mater, fons amoris	Iyá ifẹ, emi mbẹ Ọ.
Me sentire vim doloris	Mu k'emi ba Ọkànu pọ
Fac, ut tecum lugeam.	Ki mba Ọ da omije !
10	10
Fac ut ardeat cor meum.	Jẹ k'ọkàn mi gbiná gidi.

In amando Christum Deum.
Ut tibi complaceam.

11

Sancta Mater, istud agas.
Crucifixi fige plagas.
Cordi meo valide.

12

Tui nati vulnerati.
Tam dignati pro me pati.
Pœnas mecum divide.

13

Fac me vere tecum flere.
Crucifixo condolere.
Donec ego vixero.

14

Juxta crucem tecum stare.
Te libenter sociare.
In planctu desidero.

15

Virgo virginum præclara.
Mihi jam non sis amara
Fac me tecum plangere.

16

Fac ut portem Christi mortem.
Passionis fac consortem.
Et plagas recolere.

Lati fẹ́ Kristi Ọlọrun.
K'emi lè wù Ọ nidaju.

11

Iyá mimọ́, emi mbẹ̀ Ọ.
Tẹ̀ ọgbẹ ti Jesu-Kristi,
Mọ́ inu mi pupọ̀ ju.

12

Pín fun mi ninu ìjiyà.
Ti Ọmọ rẹ, t'o fẹ́ r'ikú.
Nitori igbalà mi.

13

Mu ki mba Ọ sọkun pupọ̀
Ki nṣàjo ijiyà Kristi
L'ijọ́ aiye mi gbogbo.

14

L'ẹsẹ agbelebu Jesu,
Mo fẹ́ lati ba Ọ duro
Lati ba Ọ ṣ'ọfọ̀.

15

Wundia ti ologo julọ,
Ṣe sùru, sá gbọ́ ti emi.
Jẹ ki ntù Ọ l'inu tán.

16

Jẹ ki nranti ikú Jesu,
Pẹlu ijiyà rẹ̀ gbogbo,
Lati jère t'èjẹ rẹ̀.

17	17
Fac me plagis vulnerari.	Mu k'ọkàn mi gbọgbẹ Jesu
Cruce hàc inebrari.	Ki nf'ayọ ru agbelèbu,
Et cruore Filii.	Nitori ifẹ tirẹ.
18	18
Flammis ne urar succensus.	Wundia, se alagbawi mi
Per te, Virgo, sim defensus.	L'ijọ idajọ ikẹhin :
In die judicii.	Ki nlè bọ l'ọwọ èṣu.
19	19
Quando corpus morietur.	Nigbati ara mi ba kú,
Fac ut animæ donetur	Mu ki ọkàn mi k'o wá ri
Paradisi gloria. Amen.	Ogo ti Ọrun rere. Amin.

MAGNIFICAT

Magnificat anima mea Dominum;	Ọkàn mi nyin Oluwa logo ;
Et exultavit spiritus meus in Deo salutari meo.	Ẹmí mi si nyọ si Olọrun Olugbala mi.
Quia respexit humilitatem ancillæ suæ; ecce enim ex hoc beatam me dicent omnes generationes	Nitoriti o ṣijuwò iwa irẹlẹ ọmọbiri ọdọ rẹ; sá kiyesi i, lati isisiyi lọ gbogbo iran enia ni yio mâ pè mi li ẹni alabukúnfun.

Quia fecit mihi magna qui potens est, et sanctum nomen ejus	Nitori Olodumare ti ṣe ohun ti o tobi fun mi, mimọ́ sì li orukọ rẹ̀;
Et misericordia ejus a progenie in progenies timentibus eum	Anu rẹ̀ sì mbẹ fun awọn ti o bẹ̀ru rẹ̀ lati irandiran.
Fecit potentiam in brachio suo; dispersit superbos mente cordis sui.	O ti fi agbara apa rẹ̀ hàn; o ti tú awọn ti nṣe igberaga ni ìro ọkàn wọn ká.
Deposuit potentes de sede, et exaltavit humiles	O ti mu awọn alagbara kuro l'ori itẹ́ wọn, o sì ti gbé awọn onirẹlẹ ọkàn soke.
Exurientes implevit bonis, et divites dimisit inanes.	O ti kún awọn talakà fun ohun iní, O sì ran awọn ọlọrọ̀ pada li ọwọ́ ofo.
Suscepit Israël puerum suum recordatus misericordiæ suæ.	O ti gbà Israeli ọmọ-ọdọ rẹ̀ sabẹ âbo rẹ̀, ni iranti ânu rẹ̀.
Sicut locutus est ad Patres nostros, Abraham et semini ejus in sœcula.	Gẹgẹbi o ti ṣe ileri fun awọn baba wa, Abrahamu ati fun iran rẹ̀ titi lai.
Gloria Patri, etc.	Ogo ni fun Baba, etc.

INVIOLATA

Inviolata, integra, et casta es, Maria,	Maria, iwọ jẹ wundia, ailẽri, ati mimọ́ nigbagbogbo.

Quœ es effecta fulgida cœli porta :	Iwọ li ilẹkùn ọrun t'o dâju :
O Mater alma Christi carissima !	A kí Ọ Iyá olutọ́ Kristi ọwọ́n julọ !
Suscipe pia laudum prœconia :	K'o sì tẹwọgbà ọ̀rọ iyìn ẹnu wa :
Nostra ut pura pectora sint et corpora,	Ki ọkàn ati ara wa k'o jẹ mimọ́,
Te nunc flagitant devota corda et ora.	Li adua t'a fi t'aiya t'ẹnu ranṣẹ si Ọ.
Tua per precata dulcisona,	Nipa anfani ẹ̀bẹ rẹ,
Nobis impetres veniam per sœcula.	K'a sì lè ri idarijì ẹ̀ṣẹ wa gbà pàtapàta.
O Benigna ! O Regina! O Maria !	Iwọ Maria, li Ayâba oniṣeun,
Quœ sola inviolata permansisti.	Iwọ nikan, l'o sì jẹ wundia nigbagbogbo.

TANTUM ERGO

Tantum ergo sacramentum	K'a wolẹ, k'a foribalẹ
Veneremur cernui,	Fun sacramenti mimọ́
Et antiquum documentum	Ki majẹmu lailai yẹ̀ra
Novo cedat ritui :	Fun otitọ isìn yi :
Prœstet fides supplementum	Eyi t'ailera oyé wa
Sensuum defectui.	Kò lè mọ̀, k'a mâ gbagbọ́.
Genitori, Genitoque	Lai iyìn, ọlá, ibukún,

Laus et jubilatio	Agbara at'ogo ni
Salus honor, virtus quoque,	Fun Baba ati fun Ọmọ;
Sit et benedictio ;	K'a sì mâ f'ogo kannâ
Procedenti ab utroque	Fun Ẹmi-Mimọ́, t'o jade
Compar sit laudatio.	Lati'n'awọn mejeji wá.
Amen.	Amin.

O SALUTARIS HOSTIA

O salutaris hostia !	Ẹran-ẹbọ itẹwọgbà,
Quæ cœli pandis ostium :	Iwọ t'o ṣílẹkun ọrun :
Bella premunt hostilia	Ọtá buburu nkọlu wa:
Da robur, fer auxilium.	Ran wa l'ọwọ́, tì wa lẹ́hin.
Uni trinoque Domino	K'a fi ogo ainipẹkún,
Sit sempiterna gloria.	Fun Oluwa Ẹni mẹta,
Qui vitam sine termino	Ki On lè fun wa li iye.
Nobis donet in patria.	Ainopin li ọrun rere.
Amen.	Amin.

SUB TUUM PRÆSIDIUM

Sub tuum præsidium confugimus, sancta Dei genitrix; nostras deprecationes ne despicias in necessitatibus : sed a periculis cunctis libera nos semper, virgo gloriosa et benedicta.	Iyá mimọ́ Ọlọrun, awa sá sabẹ âbo rẹ ; má ṣe gàn adura t'a gbà si Ọ li ainí wa ; ṣugbọn, Iwọ wundia ologo ati olubukún , gbà wa kuro ninu ewu gbogbo nigbakùgba.

ADURA SI JOSEFU MIMỌ, ỌKỌ MARIA WUNDIA ATI ALABO EKLESIA.

Josefu alabukún, Baba alagbatọ Jesu, ọkọ Maria wundia ologo, ati olori ará ile mimọ́ l'aiye, iwọ ti Papa mimọ́, aropo Jesu-Kristi sì yàn li alàbo ati olutọ́ gbogbo Eklesia ti Jesu-Kristi pàpà ti gbé kalẹ; fiyesi i, mo mbẹ ọ, lati gbọ́ adua mi yi ti mo gbà fun Eklesia nà, ki on sì lè, nipa agbara rẹ, là kuro ninu ewu gbogbo.

Baba alagbara ati alânu, dâbobo Papa mimọ́, awọn Episkopi (Bisopu), ati saserdoti gbogbo ti mbẹ l'iṣọkan pẹlu rẹ; k'o sì ran awọn olotitọ́ l'ọwọ́ ninu ainí wọn ati ninu idanwo èṣu; mu ki gbogbo enia fi inure wá tẹriba fun Eklesia, kuro ninu eleyi ti igbalà kòsi.

Josefu mimọ́ julọ, tifẹtifẹ ati tinutinu l'emi fi ọkàn mi ati ara mi le ọ l'ọwọ́, bi ọmọ rẹ tôtọ́; iwọ, Baba mi ọwọ́n julọ, tọju mi, k'o sì tọ́ mi si iṣẹ igbalà mi nigbagbogbo. Mu ki ìwa mimọ́ ati ifẹ́ni k'o hàn l'ọkàn mi, ki, nipa titopasẹ rẹ, emi lè dari gbogbo iṣe mi si ogo Ọlọrun, li iṣọkan pẹlu ọkàn Jesu ati Maria; lakótan gbadua fun mi ki nlè je alabapin ninu ayọ̀ alafia ti iwọ pàpà ti ni l'ijọ́ ikú rẹ. Amin.

ỌNA AGBELÈBU

IKIYESI

Anfani ti « Ọna agbelẹbu »

1° Nipa èro Papa Benedicto XIV, ọna agbelèbu je ise ifọkànsìn t'o l'anfani pupọ lati yí awọn elẹṣẹ padà si ọna ìwa rere, lati so awọn enia alainitara fun isìn Olorun di olufọkànsìn ati lati mu awọn olododo lọ siwaju ninu ìwa pipé.

2° Gegẹbi ẹkọ ti ọpọlọpọ Papa mimọ, awọn eniti'ọ nse « ọna agbelèbu pelu ifọkànsìn ati ikânu fun èṣẹ wọn, » yio jère gbogbo awọn indulgensi t'a fifun awọn onigbagbọ t'o nlọ bẹ awọn ipò mimọ t'ilú Jerusalemu wò ; a sì lè fi awọn indulgensi wọnnyi torẹ fun awọn emí t'o nwà ninu Purgatori.

3° Lati jère awọn indulgensi nâ, o ye k'a rìn gbogbo ibusọ ọna agbelèbu wò, ni fiyesi lati dide niwaju olukuluku aworan agbelèbu ati lati yí oju sipa ti ibusọ nâ, k'o sì se asaro ijiya ti Oluwa wa Jesu-Kristi.

ADURA IṢAJU.

Wò ! mo dọbalẹ l'ẹsẹ rẹ, Jesu rere mi lati se asaro ijiya mimọ ati ikú rẹ, ati jère ọpọlọpọ indulgensi ti ọna agbelèbu. A ! ki mba lè ni ânu Iyá rẹ mimọ ati itara ọpọlọpọ awọn kristiani ti, lọna yi, njère pupọ, ti sì nyọ emí pupọ kuro ninu Purgatori ! Se mi l'ôre ikorira ẹṣẹ if'ara we ìwa rere rẹ, ki nlè ye fun èjẹ iyebiye t'o ti tà silẹ fun mi.

Sancta Mater istud agas,	Iya mimọ́, emi mbẹ Ọ,
Crucifixi fige plagas	Tẹ ọgbẹ ti Jesu-Kristi
Cordi meo valide.	Mọ́ giri li ọkàn mi.

IBUSỌ I.

℣ Awa foribâlẹ fun Ọ, Jesu, a sì yìn Ọ logo.

℟ Nitoriti, nipa agbelèbu mimọ́ rẹ, l'o ti rà araiye pada.

A da Jesu lẹbi inú.

Ha! Pilatu, onidajọ buburu, kò ti pẹ to bẹ l'o fi wipe : Iwọ kò ri ẹbi kan ninu Jesu, ati pe On jẹ alailẹṣẹ; l'isisiyi iwọ da a l'ẹbi ikú itiju t'o sì buruju! Taf'o nâni iwẹwọ́ ati wiwi rẹ pe, iwọ kò l'ọwọ́ ninu ikú olododo yi, b'iwọ fi I fun awọn t'o buruju ninu awọn ọtá Rẹ! Ṣugbọn, Jesu rere mi, kini yio da fun mi lati d'ara mi l'âre nipa aṣehàn, bi, nipa did'ẹṣẹ, emi tún f'ẹnu si idajọ buburu ti Pilatu da Ọ!

Emi kì yio tún ṣe eyi mọ́, Oluwa! Mo bẹ Ọ, nipa inà nà t'o d'ọgbẹ ati ẹgàn, t'o ti gbà nitori mi, lati má tún jẹ ki nṣe bẹ mọ́.

Baba wa... Mo ki Ọ Maria... Ogo ni fun Baba...

℣ Ṣânu fun wa Oluwa.

℟ Ṣânu fun wa.

℣ Nipa ânu Ọlọrun, ki ẹmí awọn olododo t'o jẹ alaisi, simi l'alafia.

℟ Amin. — Sancta Mater, etc. — Iyá Mimọ́, etc.

IBUSỌ II.

ỳ Awa foribàlẹ, fun Ọ etc.

A gbé agbelèbu rù Jesu.

Wò! nwọn gbé ohun ijiya ti Jesu fun; yio lè rù bi? O wiwo pupọ!.... ati awọn agbara Rẹ sì bukù pupọ! On ni lati gbé e larin olè meji l'ọsán gangan, ati l'oju ọpọlọpọ enia. On ha lè sálọ bi?... Nigbati nwọn fẹ fi Jesu jọba, O sapamọ; ṣugbọn l'isisiyi ti irẹlẹ ati ìya onirùru nreti Rẹ. Ọba ogo kò sálọ. Lati ọdún mẹta lelọgbọn l'Ó ti nreti ọjọ yi: nitorinà l'O gbà, l'O fàmọra, l'O sì rù agbelèbu Rẹ pẹlu ânu ailopin, nitori ifẹ t'emi.

Kristiani, iwọ gbà agbelèbu t'Olọrun fun ọ bakannâ, bi?

Baba wa ti mbẹ l'ọrun, etc.

IBUSỌ III.

ỳ Awa foribàlẹ, fun Ọ etc.

Jesu ṣubu l'ẹkini.

B'o ti wù ki igboiya Rẹ pọ to, Jesu nipa oró t'o ti jẹ, kò lè d'ara duro l'aiṣubu labẹ ẹrù Rẹ buburu yi; ojuju melomelo ni igọn agbelèbu nda s'ejika Rẹ t'o uro! Nwọn jẹ ki idi igi gigun ati wiwo yi, mà kanlẹ. Ijiya wo ni idi igi yi ti ngbọn okuta, nfun Jesu! Mo ri agbara èjẹ t'o nsan lati inu ọgbẹ Rẹ kakiri gbogbo ode On kò tún lè rù mọ, On sì ṣubu nipa irora ati iwiwo igi nâ.

Kristiani, wò! Bi èṣẹ rẹ ti ṣ'ọwọ́n to fun Ọlọrun!

Baba wa ti mbẹ l'ọrun,... etc.

IBUSỌ IV.

Ỳ Awa foribàlẹ, fun Ọ etc.

Jesu pade Iyá Rẹ̀.

Irora nlá wo ni, iyá yio ni lati ri ki a da ọmọ rẹ̀ l'ẹbi ikú, b'otilẹ̀ jẹ̀ pe, on l'o buruju ninu gbogbo enia, ati pe, ki On sì ti ba on l'inu jẹ̀ pupọ̀! A da Maria l'ẹbi lati ri ọmọ rẹ̀ ti kò jẹbi t'o jẹ̀ mímọ́ pápá, Olufẹ ati Ọlọrun t'o d'ènia, lati ri adé ẹgún lori Rẹ̀, ati gbọ́ gbogbo ọ̀rọ̀ ẹgàn; pẹlupẹlu a da Maria l'ẹbi lati ri pe, l'ẹhin ilokilo ti nwọn lo, t'o sọ gbogbo ara Jesu d'ojuju tán, a mu Ú lọ pa l'ipa itiju! Irora nlá wo l'eyi fun Wundia mimọ́! Sugbọn o ti ọmọ rẹ̀ fun Ọlọrun Baba, o sì fẹ̀ lati padanu rẹ̀, jù lati da iṣẹ igbalà wa duro lọ.

Nje, yio dara bẹ̀, iwọ ẹlẹṣẹ, lati sọ oró irú ọmọ bayi, ati irora irú Iyá bayi d'ọtún nipa èṣẹ rẹ, bi?

Baba wa ti mbẹ l'ọrun... etc.

IBUSỌ V.

Awa foribàlẹ fun Ọ, etc.

Syrenean ba Jesu rù agbelébu.

Bawo ni ayọ̀ Simoni, ẹniti a rọ̀ ba Jesu rù agbelèbu Rẹ̀, ti pọ̀ to? Kì mba ti lè gbà ipò rẹ̀! Kì mba ti lè tù Ọ́ l'inu, Jesu rere, nipa biba

Rẹ rù ẹrù wiwo yi! Bẹni, ọmọ mi, iwọ lè tù mi linu. Gbà agbelèbu ti a fun ọ, pelu ifẹ ati ayọ, ati alafia yio pọ fun ọ jù Syrenean lọ; Iwọ yio sì ran mi l'ọwọ lati gbé agbelèbu mi. A! Bi iwọ ba mọ bi inira ati wahalà aiye yi ti n'iye l'ori to! Ṣugbọn b'o ti jẹ pe iwọ kò kà iye ailopin ti awọn ipọnju ati inira aiye yi si, iwọ mà gbà wọn pelu ibẹru, iwọ mà bú pelu ejọ wiwi, a sì mà kùn si mi.

Lôtọ ni, Oluwa, bẹni mo ṣe titi di akokò yi; ṣugbọn mo fẹ wí pelu Agustini mimọ pe: Lati isisiyi lọ Olorun mi, mo fẹ k'a sùn nì l'inú, k'a sì pọn mi l'oju b'Iwọ yio ba da mi si l'aiye ti mbọ.

Baba wa ti mbẹ l'ọrun. .. etc.

IBUSỌ VI.

Awa foribalẹ fun Ọ... etc.

Veronika rere nù oju Jesu.

Bawo ni iwa rere Veronika ti yatọ si tiwa to! Nigba t'o ri t'awọn panipani, yí Oluwa ká lati lọ pa a, ti oju Rẹ sì kún fun itọ ati èjẹ, obiri alaibẹru yi, rè awọn enia koja, o sì nù Jesu l'oju. Ṣugbọn ohun kekere kan, egàn, èru lasan tabi kini nwọn o wí to lati dẹruba awa kristiani, to lati jẹ k'a kọ ọna agbelèbu, to lati jẹ k'a kò komunioni ati gbogbo isẹ ti isìn silẹ. Ẹ wò! iyatọ ti mbẹ ninu igbẹhin wọn: Veronika dì eni mimọ, Jesu ya aworan Rẹ sinu gele t'o fi nù l'oju; ṣugbọn awọn ti kò ṣisẹ wọn, d'ojuti wọn, nwọn yio sì d'erú èṣu titi lọ.

A! Oluwa, nigbawo l'Iwọ yio gbà mi kuro ninu ibẹru enia ati ihùwa buburu yi?

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc.

IBUSỌ VII.

Awa foribâlẹ fun Ọ..,. etc.

Jesu ṣubu l'ẹkeji.

B'otilẹ ti jẹ pe Simoni Syrenean mba gbé agbelèbu Rẹ̀, Jesu sì tún ṣubu nigba keji. Ibajẹ wo, ati blasfẹmi wo l'awọn apania buburu kò wí si I l'ara! Pẹlu iwa ika wo ni nwọn kò tún lù U! Bẹ̀ni Jesu kò wijọ. On kò ni lati sàmi kan, ati ilẹ yio sì yanu l'ẹsẹ kannâ, y'o sì mì wọn lâye sinu ọrun apâdi, ṣugbọn kaka k'o ṣe yi, on fẹ jiya si, nitori ifẹ tiwa. Iṣeun yi ti tobi to! Emi kò mọ iya kan jẹ nitori ti Rẹ̀! Nipa ibajẹ kekere kan, tabi ọ̀rọ, ma bèrẹ si fi bú ati sọ̀rọ skandali. Ati b'o ti jẹ pe laisi iná ati irọ́ owu, alagbẹdẹ ọṣisẹ kò lè ṣe ife rere kan, bẹ̀ nà gẹ ni, laisi agbelèbu ati iyọnu, emi kò lè wọ́n adé mi t'ọrun.

Bẹ̀ l'o ri, Jesu, ati lati isisiyi lọ, pẹlu iranlọwọ́ ôre ọfẹ Rẹ, emi o gbà gbogbo iya t'o fi fún mi, pẹlu ayọ̀, b'o ti wù k'o lodi si iwa ara mi to.

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc

IBUSỌ VIII.

Awa foribâlẹ fun Ọ.

Jesu tù awọn ọmọ obiri ti Jerusalẹmu l'inu.

Bawo l'iwa rere ọkàn Jesu ti pọ̀ to! O gbà ìjiya Rẹ̀ gbé, lati kânu awọn obiri ti nsọkùn

tẹle l'ẹhin. O sì wipe : Ọmọ Jerusalẹmu, ẹ má sọkùn fun mi, ṣugbọn ẹ sọkùn fun ara nyin ati ọmọ nyin ! Nitori bi nwọn ṣe nkan wọnyi l'ara igi tutu, kili ao ṣe niti gbigbẹ! Eyi jasi pe, bi a ba ṣe alaiṣẹ bayi, bawo l'ao ti ṣe ẹlẹṣẹ? Bẹni ẹlẹṣẹ l'o jẹ ẹni kanṣoṣo ti kò sọkùn ; O mọ pe on wà l'iwa èṣẹ nlà ati pe bi on ba sì kú l'iwa yi, on yio jọná ninu iná ainipẹkún : ati o sì nfi eyi ṣe ẹrin rin ; on ṣire. o sì nyọ̀ pẹṣẹpẹṣẹ l'eti bèbe ọgbun buburu yi !

A ! wò b'aifoiyà, ainitiju yi ti tobi to !

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc.

IBUSỌ IX.

Awa foribâlẹ fun Ọ.

Jesu ṣubu l'ẹkẹta.

Bẹni, Jesu tún ṣubu l'ẹkẹta l'abẹ agbelèbu Rẹ̀. Ibaje, ilù, ati ìwa ikà l'ọtún l'ọtún sì tún wá lati ọwọ́ awọn Ju ; Ọtún ibanujẹ ati irora, ọtún inu rere ati t'ânu ti ọdọ Oluwa wá. O da bi pe ọrun-âpadi tú ibinu rẹ̀ ka le on l'orí. Kini Jesu yio ṣe? Njẹ ki yio pari iṣẹ Rẹ̀ ; njẹ, kio ṣe bi awa t'o jẹ pe, nipa ilodi kekere kan ao fi ọna ìwa rere silẹ bi? Agbẹdọ ! Agbẹdọ ! Nwọn lè wí fun pe : B'Iwọ jẹ ọmọ Ọlọrun sọkalẹ kuro l'agbelèbu ; ati nipataki nitoriti On jẹ ọmọ Ọlọrun, On a sì duro sibẹ titi di amidẹkun Rẹ̀.

Oluwa ! B'o ti wù k'o ri, pẹlu iranlọwọ́ ôreọfẹ Rẹ mo fẹ́ fẹ́ Ọ titi d'oju ikú.

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc.

IBUSỌ X.

Awa foribâlẹ fun Ọ... etc.

Nwọn bọ Jesu l'aṣọ. Nwọn sì fun l'orôro mu.

Ọba ogo, ẹniti nfi ewé fun igi, nfi ododo fun oke, nfi imọlẹ fun sanma, nwọn bọ aṣọ Rẹ, lọsan gangan, ati l'oju ọ̀pọlọpọ enia, ti nkẹgan Rẹ̀. Ojutì ati ìya wo leyi fun Oluwa! Bi aṣọ tilẹ mọ́ ara Rẹ, ti ẹ̀jẹ sì gbẹ mọ́ oju ọgbẹ, ẹ̀rán sì mọ́, o sì tún ṣ'ọgbẹ t'o jù ẹgbẹ̀dọgbọn wọnyi, ti awọn ẹni buburu ti da s'ara Rẹ̀ d'ọ̀tún. Bawo l'irora yi ti pọ̀ to! A! Bawo l'iwa aimọ́ ati ifẹkufẹ t'o sọ mi di ẹlẹbi, ṣ'ọ̀wọ́n fun Jesu to?

Baba wa ti mbẹ l'ọrun... etc.

IBUSỌ XI.

Awa foribâlẹ fun Ọ.... etc.

Nwọn hun Jesu mọ́ agbelẹbu.

Nwọn bọ Jesu l'aṣọ, nwọn sì ti fun l'oro ati finega mu, l'isisiyi nwọn sì paṣẹ fun k'o dubulẹ s'ori agbelẹbu. Njẹ, yio gbọ́ ti wọn bi? Laisi ani, ani. Iwọ ti nà ọwọ́ rẹ si ohun t'a kilọ fun ọ. Jesu nà ọwọ́ rẹ̀ pẹlu ki nwọn ba lè kàn l'iṣo. Gbà ipò rẹ̀. Rò pe nwọn kàn ọwọ́ rẹ ati ẹsẹ̀ rẹ l'iṣo wiwo. Iro yi mu ọ gbọn pẹlu ibẹ̀ru! Bẹ̀ni Jesu jẹ ailẹṣẹ, iwọ sì jẹbi ìya ainipẹkun. Rò ohun t'o nṣe l'ọwọ́. Irọ́ owu ba ọkàn Maria jẹ, iṣo ngùn ẹ̀rán ara Jesu, njà iṣan rẹ̀, nfọ egun rẹ̀, ati agbara ẹ̀jẹ nṣan l'ara Jesu. A! Wò b'o ti ṣọwọn fun Jesu to, ohun

ti ajaiye npè l'ohun l'asan, ati pe, boya, nipa itiju, o npamọ́ ninu ijẹwọ ẹṣẹ rẹ l'ọdọ́ saserdoti!

Jesu rere mi, má jẹ ki ntún lu ọwọ́ rẹ nipa awọn iṣẹ aimọ́, ati ki ntún kàn iṣo mọ́ ẹṣẹ rẹ. nipa irìn l'ọ̀na buburu!

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc.

IBUSỌ XII

Awa foribâlẹ fun Ọ.... etc.

Jesu kú l'ori agbelébu.

Nwọn gbé agbelèbu s'oke. nwọn sì jin i l'ojiji sinu ihò ti nwọn gbẹ s'ori òke. Idamu ati wahalà wo ni ilò aiye yi, ṣe l'ara Olugbala! Jesu de inu ìya ikú. Ẹlẹṣẹ, wò Baba rẹ! Ẹlẹda rẹ ati Olorun rẹ ni; nitori rẹ l'O njiya ikú Wí fun mi. njẹ irora kan wà t'o to ti Rẹ? Lisisiyi b'O gb'oju s'oke ọrun, on kò ri Angẹli lọpọlọpọ ti sokalẹ wá sìn I, bi inu ijù.

Idajọ Olorun ṣí gbogbo agbara rẹ le E l'ori. B'O boju wò aiye, kò gbọ́ nkán miran bikoṣe ibú ati blasfẹmi; ati kò ri ohun miran bikoṣe igbagbé ati aimôre, titi de bi pe, ibanujẹ ti iyá mu irora ọmọ pọ̀ si. A! nigba melo ni awa duro tifẹtifẹ ninu ìwa egbé? Jesu rere mi, ki emi má jẹ ọkan ninu awọn alaimôre yi, ati k'emi má tún ṣe mọ́ s'Olorun t'O dara to bẹ.

Baba wa ti mbẹ l'ọrun... etc.

IBUSỌ XIII

Awa foribâlẹ fun Ọ.... etc.

Okú Jesu l'ọwọ́ Iyá Rẹ̀.

Iyá onirora, jẹ ki nsunmọ ọmọ rẹ, ati ki mbọ Olugbala mi. Wò! b'o ti nà l'okú si aiya rẹ̀! Mà bọ, ọmọ mi; wò! bi awọ Rẹ̀ ti pada! wò! bi egún ti gún U l'ori, wò b'a ti pa aworan Rẹ̀ kalẹ! oju Rẹ̀ t'o jẹ ayọ̀ ọrun rere sì wọnu, a kún ahọn Rẹ̀ t'o ti sọ ọ̀rọ̀ rere ti aiye ainipẹkun, fun oró; awọn ẹṣẹ Rẹ̀ ti mà wá awọn ẹlẹṣẹ ká l'aisimi, dalu fun iṣo; awọn ọwọ́ Rẹ̀ t'o ti nṣe iṣẹ nlanla dalu; wò! O ti kú!...

Nisisiyi, rò idajọ Ọlọrun ati ikorira t'Oluwa ni fun ẹ̀ṣẹ; k'o dupẹ l'ọwọ́ Jesu, k'o sì bukún fun ifẹ́ ailopin ti Rẹ̀.

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc.

IBUSỌ XIV

Awa foribâlẹ fun Ọ.... etc.

Nwọn sin Jesu sinu isà okú.

Ki nwọn to sé isà okú t'o gbà iṣura ti ọrun ati aiye, ẹ tún wò Olufẹ Olugbala nyin si l'awodẹkùn. A! Nisisiyi ni mo to ri ohun ti mo pè li asan ati ire jẹ. Kini nwọn ti sọ Ọlọrun ati Oluwa mi dà! ati nipa iri ọgbẹ wọnyi, iwọ ọkàn mi sì tún lè mà d'ẹṣẹ s'Ọlọrun t'o dara to bẹ, bi? Orun, oṣupa ati awọn okuta nmì nipa ikú Jesu: ati emi nikanṣoṣo l'o ṣ'aimọ̀.

Emi yio tún pa A nipa èṣẹ mi bi? Agbẹdọ! ki nkú, ki nkú nigba ẹgbẹrun jù ki ntún ṣẹ Ọ lọ!

Baba wa ti mbẹ l'ọrun.... etc.

IṢE IJẸVỌ IGBAGBỌ

Fun awọn aṣina t'o pada wá si igbagbọ tôtọ.

Emi N. ará ilú N. t'o kunlẹ niwaju rẹ, Baba, t'o sì ni iwe mimọ niwaju mi, ti mo fi ọwọ mi le, ti mo sì mọ pe, kò si ẹnikan t'o lè ri igbalà laisi igbagbọ ti ijọ mimọ awọn Roman katoliki ati apostoliki pamọ, gbagbọ, t'o sì kọ ni, eyiti inu mi bajẹ pupọ, nitoriti mo ti ṣina si i nipa gbigbà ẹkọ ti o lodisi ẹkọ rẹ gbọ. Nisisiyi emi ti ôre-ọfẹ Ọlọrun ṣí l'oju lati ri iṣina mi, jẹwọ pe mo gbà ijọ mimọ awọn Roman katoliki ati apostoliki gbọ bi ijọ awọn kristiani olotitọ nikanṣoṣo, ti Jesu-Kristi dá silẹ lori aiye yi, eyiti mo tẹriba fun tọkàntọkàn. Mo gbà gbogbo awọn otitọ ti on gbé kalẹ niwaju mi lati gbagbọ gbọ; mo sì kọ gbogbo ẹkọkẹkọ ti on kọ, t'o sì da lẹbi silẹ; mo sì mura lati pa ohun gbogbo ti on pa l'aṣẹ fun mi mọ; ati nipataki mo jẹwọ pe mo gbà awọn otitọ ti o tẹlẹ iwọnyi gbọ wipe: Ọlọrun kan ninu ẹni meta t'o yatọ si ara wọn, ṣugbọn ti o dogba pẹlu ara wọn, eyini pe: Baba, Ọmọ ati Emi-Mimọ, pẹlu ẹkọ awọn Katoliki ni ti isọ Ọmọ Ọlọrun di enia; ijiya, ikú, ajinde kuro n'isà okú, ati idapọṣọkan

ẹnikan, pẹlu ìwa meji, ìwa Ọlọrun ati ìwa enia ti Oluwa wa Jesu-Kristi; sibẹsibẹ mo gbagbọ pe Maria mimọ jẹ Iyá Ọlọrun ati pe o jẹ wundia alaibawọn nigbagbogbo.

Mo sì gbagbọ pe Oluwa wa Jesu-Kristi mbẹ l'otitọ ati l'ododo pẹlu ara, èjẹ, ẹmì ati ìwa Ọlọrun rẹ̀ ninu sakramenti Ukaristi mimọ labẹ aworan akara; ati pe a nyí akara pada s'ara rẹ̀ ati ọti ¸yini, si èjẹ rẹ̀, eyiti a npè ni iparada.

Mo sì gbagbọ pe Jesu-Kristi ti da sakramenti meje silẹ fun igbalà araiye, eyini pe Ibatisi, Konfirmasi, Ukaristi mimọ, Penitensi, Extrem-Unksi, Ordini mimọ ati Matrimoni.

Mo sì gbà Purgatori tabi ibi atubọ wẹnumọ, ajinde awọn okú ati ìye ainipẹkun gbọ.

Mo sì gbagbọ pe Papa ti mbẹ ni Roma, t'o jẹ agbipò Piteru mimọ, Olori awọn Apostoli, t'o sì jẹ arọpò Jesu-Kristi, kò jẹ kiki Olori ti gbogbo awọn Kristiani nipa ọlá nikan, ¸sugbọn nipa aṣẹ pẹlu.

Mo sì gbà ibọlá fun awọn Enia mimọ ati awọn aworan wọn gbọ. Mo sì gbà ẹkọ atọwọdọwọ awọn Apostoli ati ti iwe mimọ gbọ, eyiti o tọ k'a ṣe itumọ rẹ̀, k'a sì ni oyé rẹ̀ gẹgẹbi itumọ ti ijọ mimọ awọn Katoliki, iyá mimọ wa ti ṣe, t'o sì pamọ. Mo sì gbà gbogbo ohun miran gbọ, eyiti awọn olùkọ mimọ ati awọn ijọ igbimọ rẹ̀, nipataki ijọ igbimọ mimọ ti ilú Trenti ati ti ilú Roma ti fi asọyé rẹ̀ mulẹ, ti wọn sì ti sọ itumọ rẹ̀.

Nitorinà, tọkàntọkàn ati pẹlu igbagbọ laisẹtan ni mo koriragbogbo ẹkọ ati gbogbo igbagbọ eké, ati gbogbo ẹgbẹ onigbagbọ t'o lodisi ijọ

mimọ́ awọn Roman Katoliki ati Apostoliki; mo sì fi ibura kọ́ wọn silẹ. Ki Ọlọrun ati iwe mimọ́ yi ti mo fi ọwọ́ mi le k'o ran mi l'ọwọ́ lati lè ṣe bẹ́. Amin.

ROSARIO

Rosario ni iṣẹ ifọkansìn kan, ti Ọlọrun jẹ Olupilẹṣẹ rẹ̀, ti Maria Wundia mimọ́ sì ṣọ di mimọ́ fun Domingo mimọ́ nìwọn ẹgbẹta ọdún t'o koja nisisiyi.

A fi ijẹwọ́ igbagbọ́ ti awọn Apostoli, adura Oluwa, ati ikí Angẹli kún Rosario.

Nigbat'a kà Rosario, o tọ́ k'a rònu si misteri tabi ọrọ-ijinlẹ kan, t'o tàn si aiye ti Oluwa wa Jesu-Kristi, ati ti Maria mimọ́ nisaju adura Oluwa kọkan.

Lati kà Rosario, a mu agbelèbu dani, lori eyiti a kà : Mo gbà Ọlọrun Bada Olodumare gbọ́, etc.

Lori eyọ nla kọkan ti Rosario, a kà : Baba wa, etc., ati lori awọn eyọ kekeke, a kà : Mo kí Ọ Maria, etc.

Lẹhin ipari wọn, a fi adura : Ogo ni fun Baba, etc., kún u làrin kan gẹgẹ bi o ti ri l'ara Rosario.

Bi a ba fi ikiyesi ati ifọkànsìn kà Rosario, a lè jère ọpọlọpọ indulgensi.

Rosario ni ori mẹ̀dogun; li ori kọkan a rònu si misteri kan t'o tẹle yi.

MISTERI, TABI ỌRỌ-IJINLẸ TI ROSARIO

I

MISTERI ALAYỌ MARUN

Misteri ekini t'o l'àyọ̀ li ijisẹ Angẹli fun Maria Wundia.

Angẹli Gabrieli ti a ran lati ọdọ Ọlọrun lọ si ilú Nasareti, sọ fun Maria pe Ọlọrun ti yàn a lati jẹ iyá Olugbala araiye.

Wò ọdọmọbiri Oluwa, ki o si ri fun mi gẹgẹ bi ọ̀rọ rẹ, ni Maria wí. Lojukannà a sọ Ọrọ di Ara, o si bọ̀ ogo rẹ̀ silẹ, o si tẹwọgba àwọ iranṣẹ fun ara rẹ, o mba wa gbé, o si kún fun ôre-ọfẹ ati otitọ.

Iwọ Ọlọrun, t'o rẹ̀ ara rẹ silẹ, wá sinu ọkàn mi, k'o si kọ́ mi l'ẹkọ́ nla ti ọkàn rẹ.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ninu misteri yi ni, *Iwà irẹlẹ.*

Ekeji : Ibẹwó ti Maria fun Elizabeti, ará rẹ̀.

Lẹhin igbati Maria ti gbọ́ lati ẹnu Angẹli wá pe, Elizabeti arabiri rẹ̀ ti loyún, o lọ kankan s'ilẹ òke ti Judea lati kí i, ati lati yọ̀ fun u. Nigbati o de ibẹ, gbogbo ará-ile nà kún fun ôre-ọfẹ ati ayọ̀. Elizabeti si sọ asọtẹlẹ, o kọrin ogo ti iyá Ọlọrun, a si sọ Johani Baptisti di mimọ́ ninu iyá rẹ̀, nipa ohùn didùn ti Maria.

Iwọ, Jesu, nigbawo l'emi yio lè ṣe òre ânu kan lati fi ran ẹnikeji mi lọwọ́, gẹgẹ bi Maria mimọ́ ti ṣe.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe k'a *fẹ ẹnikeji wa bi ara wa.*

Ẹkẹta : Ibi Jesu-Kristi.

Ẹ jẹ k'a fi ìro lọ si ibujẹran Bethlehemu, k'a si ba Maria Wundia ati Josefu mimọ́ foribalẹ fun Ọmọ Ọlọrun, ti a bí loganjọ, l'akokò ọdún ti otutu mu julọ, ati ninu ìwa ọ̀si pâpâ ; Maria mimọ́ sì fi ọja wé E, o sì tẹ Ẹ sinu ibujẹ ẹran, nitori akete kò si fun U. Ha ! bi ìro Ọlọrun ti lodi si ti araiye to ! Jesu ti yàn ìwa talakà, araiye sì fẹ́ kiki ọlá ati irọra aiye nikan. Lai mo fẹ ran ara mi leti pe, ọmọ-ẹhin Ọlọrun t'o jẹ talakà, t'o rẹ ara rẹ silẹ, t'o sì jiya, l'emi nṣe.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni *k'a ya ara wa kuro ninu ohun t'aiye yi.*

Ẹkẹrin : Ifihàn ti Jesu-Kristi n'ile Ọlọrun.

Nipa iṣẹ Maria, ati l'ọna gbangba, ati bi o ti tọ́ si nipa otin, ni Jesu-Kristi ṣọ ẹbọ ara rẹ tikalarẹ. t'o ti rù l'akokò kini ti isọdi Enia rẹ, d'ọtún. O wù U ki a rà A pada li owo fadaka diẹ, O sì teriba fun otin kan ti kò lè kàn A rara, gẹgẹ bi otin iwẹnùmọ kò ti kàn iyá rẹ, ti jẹ Wundia nigbagbogbo ; ṣugbọn o wá si aiye lati teriba, yio sì teriba titi di oju ikú, ani ikú lori agbelebu. Ṣugbọn awa nisisiyi, bawo li a ti wá awawi to lati yẹ iṣẹ wa bi kristiani silẹ ?

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a teriba fun otin Ọlọrun.*

Ẹkarun : Iri Jesu-Kristi ninu tempeli.

Lati dan ifé Maria wò ni Jesu fé duro jina si iyá rẹ̀ niwọn ijó meta ; Maria mimó sì fi ayọ̀ ati ibanujẹ nla wá A kiri. Bawo ni ayọ̀ rẹ̀ ti pọ̀ to, nigbati o ri ọmọ rẹ̀ Jesu ni ile Olọrun, o joko lârin awọn olukọni ! Nigbati Jesu-Kristi bẹ̀ wa wò, ẹ jẹ́ k'a duro tì i pẹlu irẹlẹ ọkàn ; bi On ba sì lọ kuro l'ọdọ wa, ẹ jẹ́ k'a wá A kiri pẹlu ireti ṣinṣin ati iṣotitọ̀ alailèyí fun ipinnu rere wa.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a ni igboiya ninu idanwò.*

II

AVỌN MISTERI ONIBANUJẸ́ MARUN

Ekini : Adua ati ilâgùn èjẹ ti Jesu-Kristi ninu Ogba Getsemani.

Lẹhin igbati Jesu-Kristi ti da sakramenti Ukaristi mimó silẹ̀ tán, O mu ọ̀na rẹ̀ pọn lọ si agbala Getsemani. Nibẹ̀, bi Ontikalarẹ̀ ti ri pe èṣẹ awọn araiye gbogbo wà li ọrùn rẹ̀, bi o sì ti mọ̀ pe On yio jiya lasan fun ọ̀pọlọpọ enia, nigbanâ ni inu rẹ̀ bajẹ pupọ, tobẹ̀ ti èjẹ fi njade li ara rẹ̀. Didojubolẹ ati kikún fun ôgun èjẹ li On fi gbadura, o sì fi ara rẹ̀ le ododo lile ti Olọrun l'ọwọ́ Bayi ni ẹni alailẹbi èṣẹ ṣe etutu fun èṣẹ, ati, awa t'o jẹ ẹlẹbi tôtọ, o kò tilẹ̀ ni omije l'ojù !

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a korira èṣẹ*

Ekeji : Inà Jesu-Kristi ni paṣán.

A dè Olugbala araiye mọ́ aròpodogiri. A sì ya ara rẹ̀ alailẹbi pẹrẹpẹrẹ. Lati ateṣẹṣẹ rẹ̀ titi fi de ori, kò si ilera ninu rẹ̀ bikoṣe ọgbẹ, ni woli Isaia wí. Awọn olupani sì tún nlû U sibẹsibẹ. Bawo ni riro ìjiya yi ti dun to li ọkàn iyá rẹ̀ mimọ́ !

Ọmọ Olọrun, ọrẹ ọkàn mi, èṣe ti iwọ fi jiya pupọ to bẹ̀? Ọmọ mi, mo jiya to bẹ̀ lati ṣe etutu fun irekoja ati ijaiye rẹ

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a pọn ara wa l'oju.*

Ẹkẹta : Ifi adé ẹgún dé Olugbala wa lori.

Awọn ọmọ ogun, t'o n'ika pupọ, tún mu ìjiya inà nipaṣán rẹ̀ pọ̀ si i Sakiyesi i, nwọn fi Jesu ṣe ọba ẹlẹya; nwọn wọ̀ Ọ li aṣọ igunwa ododo, nwọn sì fi ọpa aparọn le E lowọ́ bi ọpa ọba, nwọn sì wún adé ẹgún kan, ti nwọn fi tipatipa tẹ mọ́ ori rẹ̀ mimọ́.

Jesu ti iṣe Olọrun ti fi idakẹjẹ jiya irú ẹgan wọnyi ; ati awa, ẹdá ẹlẹṣẹ, kò mọ̀ iyọnu t'o kerejù gbà laiṣe irahùn.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a mu sûru.*

Ẹkẹrin : Jesu rù agbelebu rẹ̀.

Ẹ jẹ k'a tẹ̀ oju ọkàn wa mọ́ Olugbala araiye, ẹnit'o ngoke lọ si ori òke Kalfari ti on ti igi agbelebu t'o gùn, t'o sì wuwo l'ejika rẹ̀.

Li iṣisẹ kọkan ti on ṣí, o ta gbọngbọn ; o ṣubu lulẹ̀ làrin mẹta, o sì dide làrin mẹta, ki iṣe nipa ninà ti awọn ọtá rẹ̀ nnà ni, ṣugbọn

nitori ifẹ́ nla rẹ̀ si araiye. Iyá rẹ̀ sì tọ̀ Ọ lẹhin ni ipasẹ̀ èjẹ rẹ̀. O sì pín ninu ìjiya rẹ̀ pẹlu ifẹ́ ti a kò lè tiwe. Li apẹrẹ iyá onibànujẹ yi ati ti Simeoni, ará Sireni, ẹ jẹ́ k'a ran Jesu-Kristi l'ọwọ́ lati rù agbelebu rẹ̀ nipa rirù tiwa pẹlu itẹriba, ati ifẹ́, ati iroju titi.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a fi ara wa le ifẹ́ Ọlọrun l'ọwọ́.*

Ẹkarun : Ikàn mọ́ igi agbelebu ti Olugbala araiye.

Jesu bẹrẹsi iṣẹ iṣẹ nla ti irapada araiye. Iwọ ọkàn mi, tẹjumọ Ọlọrun rẹ ati Oluwa rẹ, ti a kàn mọ́ agbelebu, t'o sì kú nitori rẹ, lẹhin igbati O ti fun ọ li iyá rẹ̀, itoyé rẹ̀, ati èjẹ rẹ̀. Maria mimọ́ sì gbà ìgún ọ̀kọ̀ t'o gún Ọmọ rẹ̀ l'ọkàn, o sì duro lẹba agbelebu, o dù ara rẹ̀ li ohun gbogbo.

Iwọ Olugbala olufẹ, nigba wo l'emi yio kọ́ lati dù ara mi, ati lati jẹ tirẹ pátápátá.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a dù ara wa, k'a sì dì okú si ara wa.*

III

AWỌN MISTERI OLOGO MARUN

Ekini : Ajinde Jesu-Kristi.

Jesu, aṣẹgun ikú ati ọrun apàdi, o farahàn ti on ti ogo lori okuta ibojì rẹ̀, Ha! bi iyipada ara rẹ̀ ti ya ni l'ẹnu to! Adé aikú ti rọpo adé ẹgún, awọn ẹgbẹ rẹ̀ sì tanmọlẹ bi orun. Pẹlu ifẹ́ nla ati ọ̀wọ̀ wo ni Maria kò ba ti fẹnuko

ọgbẹ mimọ́ wọnyi, nigbati ọmọ rẹ Ọlọrun farahàn niwaju rẹ! Jesu, Iwọ li ajinde ati ìye; gẹgẹ bi Iwọ li emi yio jinde n'ijọ́ kan; pẹlu re lati onioloni lọ li emi yio hùwa bi ti ọrun, ti isẹgun re lori ikú li ipilẹsẹ ati apẹrẹ rẹ.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a yipada si Ọlọrun pátápátá.*

Ekeji : Igoke rè ọrun ti Jesu-Kristi.

Lori òke Olifi ni Jesu-Kristi ya ara rẹ kuro lârin awọn ọmọ-ehin rẹ, o si gòke lọ si ọrun ti On ti ọlá nla; Ó fi aiye silẹ. ṣugbọn ni bibukún fun O bukún fun u. Nigbati oju rẹ tẹmọ́ oju ọrun, awọn ọwọ́ rẹ tẹ silẹ. Loke ọrun, Baba rẹ ati ogo rẹ npè E, nisalẹ, awọn ọmọ-ehin rẹ ati iyá rẹ mimọ́ si nda ọkàn rẹ duro lodọ wọn. Bawo li awa ti lè wà laisi rẹ, Iwọ Jesu Olugbala? Jẹ ki sùru tù osi mi ninu t'ile ajẹji yi, ki o si mu mi sunmọ ọdọ rẹ si i lojojumọ.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a ni ifẹ ọrun rere*

Ẹkẹta : Isokalẹ Ẹmi Mimọ́ wá sori awọn Apostoli.

Maria Wundia ati awọn Apostoli pejopọ ninu yara kan, nwọn ngbadua, nwọn si ndurode Ẹmi Mimọ́, ti Jesu-Kristi ti ṣe ileri fun awọn. Ẹmi Mimọ́, t'o ti ọdọ Baba ati Ọmọ jade wá, li a rán lati ọwọ́ wọn wá aiye, li ọjọ́ Pentekosti. O wá lati sọ otitọ ti Jesu-Kristi ti kọ́ awọn apostoli rẹ di yiyé, ati lati mu òreọfẹ ti on ti jère seso li ọkàn enia.

Lati ijọ nà lọ ni Ẹmi Mimọ gbé ninu Eklesia ati olukuluku enia ; o mí sì wa, o sì gbà wa niyanju, o sì sọ wa dì alâye, nipa imọlẹ ati ifẹ rẹ. Ẹmi Mimọ, nigbawo li ao pọn ara wa loju, ti a sì paramọ to lati tẹle imísi rẹ ninu ohunkohun, ati lati lùwa gẹgẹ bi imọran rẹ.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a jẹ olótọ si ôre-ọfẹ.*

Ẹkẹrin : Igbegoke lọ s'ọrun ti Maria Wundia.

Nigbati Jesu-Kristi goke rè ọrun, o fi Maria mimọ silẹ fun Ijọ awọn enia rẹ bi iyá ati alafẹhintì wọn. Ṣugbọn akokò ti Ọgbọ́n aiyeraiye ti da pé. Nipa iyanju ikẹhin ti ọkàn rẹ ṣe, iyá Olugbala wa ṣe èwọn ti o dè e mọ́ aiye yi, o sì fi aiye silẹ. o sì tọ Ọmọ rẹ Ọlọrun lọ li ọrun rere.

Ẹ jẹ k'a yọ nitori alafia rẹ, k'a sì bẹ lati fà wa lọ sodọ rẹ.

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *k'a bère ôre-ọfẹ ikú rere.*

Ẹkarun : Ifi adé dé Maria Wundia lori li ọrun rere

Nigbati a gbé Maria mimọ lọ si ọrun, awọn Angẹli bi ara wọn lère wipe : Tani ẹniti ngoke lati aginju wá, t'o sì kún fun ayọ nla ? Nigbati nwọn mọ pe Maria mimọ ni, inu wọn dùn gidigidi. Gbogbo awọn ọmọ-ogun ọrun sì sure lati pade rẹ, nwọn sì fi ihó ayọ nla sìn i lọ siwaju itẹ Ẹnimẹta lọkan mimọ. Jesu sì fi ikẹ ọmọ ati ọlá nla Ọlọrun gbà a, o sì mu u tọ

Baba rẹ lọ, o sì fi adé ogo dé e lori, o sì fi i jẹ Iyalode ọrun ati aiye.

Tani yio lè sọ ogo Maria jade? Tani yio sọ agbara rẹ lọdọ Olọrun?

Eso t'o yẹ k'a ba kà ni pe *h'a gbẹkẹle Maria Wundia mimọ.*

ỌDUN MIMỌ TI IRANTI ỌJỌ TI A LOYUN MARIA WUNDIA LAILABAWỌN ÈṢẸ AKỌṢẸ.

Li ọjọ 8º ti oṣù Desemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Emi o yọ gidigidi ninu Oluwa, ọkàn mi sì kún fun ayọ ninu Olọrun mi, nitorì o ti fi aṣọ igunwà ti igbalà wọ mi; o sì ti fi aṣọ ododo bò mi gẹgẹ bi iyawo ti ifi gbogbo ohun ọṣọ ṣe ara rẹ lọṣọ. *P's.* Emi o kokikí rẹ yikà, Oluwa, nitori iwọ ti gbé mi soke, ti iwọ kò sì fi àye fun awọn ọtá mi lati yọ mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun, Iwọ ẹniti, nipa mimu ki a loyún Wundia ni lailabawọn èṣẹ akọṣẹ, ti pèse ibugbé ti o yẹ silẹ fun Ọmọ rẹ, tifunni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, pe bi iwọ nipa mimọ ikú Ọmọ rẹ nà tẹlẹ, ti pa Wundia nà mọ kuro ninu gbogbo abawọn èṣẹ, bẹ gẹgẹ ni, nipa ẹbẹ rẹ, ki a lè de ọdọ rẹ lailẹṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Owe Sal. 8).

Oluwa ti ní mi lọdọ rẹ ni ipilẹṣẹ ọna rẹ, ki On to dá ẹdá kan. A ti yàn mi lati aiyeraye wá ; lati ojó lailai wá, ki a to dá ilẹ aiye. Awọn ibú okun kò ti isi, nigbati a ti loyún mi ; awọn orisun omi kò ti isun jade lati inu ilẹ ; a kò sì ti ifi idi ẹrù wuwo awọn òke nla kalẹ ; a ti bí mi ṣáju awọn òke. On kò ti idá ilẹ aiye, tabi awọn odò, tabi awọn igun mẹrẹrin ti aiye. Nigbati o nṣe ipilẹ awọn ọrun, emi wà nibẹ ; nigbati o fi osuwọn ayika le oju ibú, ti o sì fi ofin alailèdakọja fun wọn ; nigbati o fi ẹṣẹ ofurufu mulẹ soke ilẹ aiye, ti o sì fi awọ-sanma kọ soke ; nigbati o wọn awọn orisun omi lọgbọgba ; nigbati o pàla fun okun, ti o sì fi ofin rẹ fun omi ki o máṣe kọja àla rẹ, nigbati o ṣe ipilẹ aiye, mo wà pẹlu rẹ, mo sì bá a làna ohunkohun. Mo wà ni inudidùn lojojumọ, emi sì nyọ niwaju rẹ nigbagbogbo, emi sì nyọ lori ilẹ aiye ; inudidùn mi sì ni lati wà pẹlu awọn ọmọ enia. Nje nisisiyi, ẹnyin ọmọ mi, ẹ gbọ ti emi : alabukún fun li awọn ti o tẹle ọna mi. E gbọ ẹkọ mi, ki ẹnyin ki o sì gbọn, ki ẹ má sì ṣe kọ o silẹ. Alabukún fun li ẹniti o gbọ ti emi, ti o nṣọ ẹnu ọna ile mi lojojumọ, ti o sì nduro ti òpo ẹnu ilẹkùn mi. Nitoripe ẹniti o ri mi, yio ri ìye, yio sì ri igbalà gbà lọwọ Oluwa.

Graduali. Maria Wundia, iwọli ẹniti Oluwa, Olọrun Ọgá-ogo, ti bukúnfun jù gbogbo awọn obirin ti mbẹ lori ilẹ aiye lọ. Iwọ ni ogo Jerusalemu, iwọ ni ayọ Israeli, iwọ sì li ọlá awọn

enia wa. Alleluia, alleluia. Iwọ ni ẹ̀wa gbogbo, Maria, kò sì sí abawọ́n ẹ̀ṣẹ̀ akọṣẹ̀ lara rẹ̀. Alleluia.

Ihin rere (Luk. 1, 26).

Nigbanâ ni a rán Angẹli Gabrieli lati ọdọ Ọlọrun lọ si ilú kan ni Galili, ti a npè ni Nasareti, si Wundia kan ti a fẹ́ fun ọkọnri kan, ti a npè ni Josefu, ti idile Dafidi; orukọ Wundia nâ a sì mâ jẹ́ Maria. Angẹli nâ si tọ̀ ọ wá, o sì wí fun u pe: Mo kí ọ, iwọ ti o kún fun ôre-ọfẹ; Oluwa mbẹ pẹlu rẹ̀: alabukún fun ni iwọ ninu awọn obirin.

Ifitọrẹ Mo kí ọ, Maria, o kún fun ôre-ọfẹ; Oluwa mbẹ pẹlu rẹ; alabukún fun ni iwọ ninu awọn obirin. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, fi ojurere gbà ẹbọ igbalà ti awa nrú si Ọ li ọdún mimọ́ yi, ti a nṣe li iranti ọjọ́ ti a loyún Maria Wundia alabukún fun lailabawọ́n ẹ̀ṣẹ̀ akọṣẹ̀, ki o sì fifun ni, pe bi awa ti jẹwọ́ pe, nipa ôre-ọfẹ rẹ̀, a ti pa a mọ́ kuro ninu gbogbo abawọ́n ẹ̀ṣẹ̀, bẹ̀ gẹgẹ ni, nipa ẹbẹ rẹ̀, ki a lè bọ kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wa; nipasẹ̀ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Komunioni. Ohun ologo li a nsọ niti rẹ̀, Maria, nitori Olodumare ti ṣe ohun ti o tobi fun ọ.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa Ọlọrun wa, jẹ ki sakramenti mimọ́

ti awa ti gbà ki o lè wò ogbẹ ẹ̀ṣẹ nà jina ninu wa, kuro ninu eyiti iwọ ti pa Maria Wundia alabukún fun mọ li ọna iyanu nigbati a loyún rẹ lailabawọn ẹ̀ṣẹ akọṣẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ IFIHÀN JESU-KRISTI NINU ILE ỌLỌRUN ATI IWẸNUMỌ TI MARIA WUNDIA MIMỌ.

Li ọjọ 2ⁱ ti oṣù Februari.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ọlọrun, awa ti nri ânu rẹ gbà lârin ile mimọ rẹ. Ọlọrun, gẹgẹ bi orukọ rẹ, bẹ̀ni iyìn rẹ tànka titi de opin ilẹ aiye; ọwọ́ ọtún rẹ sì kún fun ododo. *Ps.* Eni-nla li Oluwa, o sì yẹ ki a yìn i pupọ̀pupọ̀ ni ilú ti Ọlọrun wa, li òke mimọ́ rẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati aiyeraiye, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹ̀bẹ lọdọ Ọlá nla rẹ, tifunni, pe bi a ti mu Ọmọ bibí rẹ nà kanṣoṣo wá tìhàn ninu tempeli li ọjọ́ oni, ninu ìwa ẹdá ara wa, bẹ̀ gẹgẹ ni ki a lè mu wa wá sọdọ rẹ pẹlu ọkàn mimọ́; nipasẹ Jesu-Kristi kannà Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Mal. III, 1).

Eyi ni Oluwa Ọlọrun wí: Kiyesi i, emi rán

Angẹli mi, on o sì tún ọna mi ṣe niwaju mi. Ati lojukannâ li Alakoso ti ẹnyin nwá, ati Angẹli majẹmu ni ti ẹnyin nṣe afẹri, yio wá sinu tempeli rẹ. Kiyesi i, o mbọ, ni Oluwa awọn ọmọ-ogun wí. Tani yio si lè rò ọjọ wiwá rẹ? Tani yio si lè duro niwaju rẹ? Nitoriti on yio dabi iná ti o yọ irin, ati bi eweko ti awọn alagbafọ nlò. Yio joko bi ẹniti nyọ, ti o si ndà fadaka; yio si wẹ awọn ọmọ Lefi mọ, yio si dà wọn bi wura ati fadaka, nwọn yio si rúbọ si Oluwa ni ododo. Ẹbọ ti Juda ati ti Jerusalemu yio si dùnmọ Oluwa gẹgẹ bi ti awọn ọjọ igbani, ati bi ti ọdún atijọ, ni Oluwa Olodumare wí.

Graduali. Oluwa, awa ti nri ânu rẹ gbà lârin ile mimọ rẹ. Olorun, gẹgẹ bi orukọ rẹ, bẹni iyin rẹ tànka titide opin ilẹ aiye; ọwọ ọtún rẹ si kún fun ododo. Bi awa ti gbọ, bẹni awa ri, ni ilú Olorun wa, ati ni òke mimọ rẹ. Alleluia, alleluia. Okonri arúgbo kan gbé Ọmọ ọwọ nâ si apa rẹ: Ṣugbọn Ọmọ ọwọ nâ ṣakoso okonri arúgbo nâ. Alleluia.

(Lehin ijọ ọsẹ Septuagesima, lipò Alleluia, etc., a wí eyiti o tẹle yi:)

Nisisiyi, Oluwa, jọwọ ọmọ-ọdọ rẹ lọwọ lọ li alafia, gẹgẹ bi ọrọ rẹ; nitoriti oju mi ti ri Igbalà rẹ nâ, ti iwọ ti pèse silẹ niwaju enia gbogbo, bi imọlẹ ti yio mọlẹ fun awọn keferi, ati bi ogo Israeli awọn enia rẹ.

Ihin rere (Luk. II, 22).

Nigbati ọjọ iwẹnumọ ti Maria ti pé gẹgẹ bi

ofin Mose, nwọn gbé Jesu wá si Jerusalemu lati fi fun Oluwa, bi a ti kọ ọ sinu iwe ofin : Gbogbo ọmọkọnri ti o ṣe akọbí li a o yà si mimọ fun Oluwa ; ati lati rubọ, gẹgẹ bi a ti kọ ọ sinu ofin Oluwa, àdaba meji, tabi ọmọ ẹiyẹle meji. Si kiyesi i, ọkọnri kan ti a npè ni Simeoni wà ni Jerusalemu ; ọkọnri nâ si jẹ olôto ati onibẹru Ọlọrun, o si durodè itunu Israeli, Ẹmi-Mimọ si wà lara rẹ. A si ti fi hàn a lati ọdọ Ẹmi-Mimọ nâ wá pe, on kì yio ri ikú, ki on to ri Kristi ti Oluwa. O si wá sinu tempeli nipa imisi Ẹmí Ọlọrun. Nigbati awọn obi si gbé Ọmọ ọwọ Jesu wá sibẹ nâ, lati ṣe fun u gẹgẹ bi o ti tọ si nipa iṣe ofin, o gbé e li apa rẹ; o si fi ibukún fun Ọlọrun, o wipe : Nisisiyi, Oluwa, jọwọ ọmọ-ọdọ rẹ lọwọ lọ li alafia, gẹgẹ bi ọrọ rẹ ; nitoriti oju mi ti ri Igbalà rẹ nà, ti iwọ ti pèse silẹ niwaju enia gbogbo, bi imọlẹ ti yio mọlẹ fun awọn keferi, ati bi ogo Israeli, awọn enia rẹ.

Ifitọrẹ. A dà ôre-ọfẹ si ọ li ète. Nitorinà ni Ọlọrun mbukún fun ọ lailai.

Adura ti a hà jẹjẹ.

Oluwa, gbọ adura wa, atipe, ki ẹbun ti a nrú si Ọ ki o lè ye fun Ọlá nla rẹ, fi iránlọwọ ànu rẹ fun wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. A ti fihàn Simeoni lati ọdọ Ẹmi-Mimọ wá pe on kì yio kú, ki on to ri Kristi ti Oluwa.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa Ọlọrun wa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fifun ni, ki sakramenti mimọ́ ti iwọ ti fifun wa lati pa wa mọ́ ninu ôre-ọfẹ iye titun wa nipa ẹ̀bẹ Maria Wundia alabukún fun, ki o lè jẹ ohun imularada fun wa li igba isisiyi, ati li igba ti mbọ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ JOSEFU MIMỌ, ỌKỌ MARIA WUNDIA MIMỌ

Li ọjọ́ 19ᵉ ti oṣù Marṣi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Olododo yio gbà bi igi ọpẹ; yio dàgba bi igi sedari ni Libanoni, on ti a gbìn ni ile Oluwa, ni agbalá Ọlọrun wa. *Ps.* Ohun rere ni lati mâ yìn Oluwa, ati lati mâ kọrin si ogo orukọ rẹ, Ọgá-ogo. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, jẹ ki a lè ràn wa lọwọ́ nipa itoye Ọkọ iyá mimọ́ rẹ, pe, ohun wọnyi ti awa kò lè ri gbà nipa agbara awati-kalawa, ki a lè fi wọ́n fun wa nipa ẹ̀bẹ: Iwọ ti o wá, ti o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba ninu iṣọkan Ẹmí-Mimọ́, lai Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun. Amin.

Epistoli (Ekles. XLV).

Ọlọrun ati awọn enia ti fẹran rẹ̀, iranti rẹ̀ sì

tún wà ni ibukún. Oluwa ti fun u li ogo bi ti awọn Enia mimọ́, O sì ti sọ ọ di ẹni-nla ati ẹni-ibẹ̀ru fun awọn ọtá rẹ̀; O sì ti mu iyonu nlanla dopin nipa ọ̀rọ rẹ̀; O gbé e ga logo niwaju awọn ọba, O sì fun u li ofin rẹ̀ niwaju awọn enia rẹ̀, O sì ti ogo rẹ̀ hàn fun u. O ti sọ ọ di mimọ́ nipa otitọ ati ìwa tutù rẹ̀, o sì ti yàn a lârin gbogbo awọn enia. Nitoriti Ọlọrun ti gbọ́ tirẹ̀, o sì ti gbohùn rẹ̀, O sì mu u wọ̀ inu awọ-sanma. O sì fun u li ofin rẹ̀ li oju rẹ̀, ati ofin ìye ati ọgbọ́n.

Graduali. Oluwa, iwọ ti fi ibukún didùn kò o li ọ̀na, iwọ fi adé okuta iyebiye dé e lori. O tọrọ ẹmí lọwọ́ rẹ, iwọ sì fun u li ọjọ́ gigùn lai ati lailai. Olododo yio gbà bi igi ọpẹ, yio sì dàgba bi igi sedari ni Libanoni.

Traktu. Alabukún fun li ẹniti o bẹ̀ru Oluwa, ti inu rẹ̀ sì dùn jọjọ li ofin rẹ̀. Irú-ọmọ rẹ̀ yio lagbara li aiye : iran awọn olododo li ao bukún fun. Ogo ati ọrọ̀ yio wà ni ile rẹ̀, ododo rẹ̀ yio sì duro lailai.

Ihin rere (Mat. 1, 18).

Nigbati a ti fẹ́ Maria, iyá Jesu, fun Josefu, ki nwọn to gbé pọ̀, a ri i, ti o lóyun nipa agbara Ẹmí-Mimọ́. Ṣugbọn Josefu, ọkọ rẹ̀, ti ise olododo enia, ti kò sì fẹ́ ṣàbukùn fun u nigbangba, o pinnu lati kọ̀ ọ silẹ ni ìkọkọ. Bi o sì ti nrò nkan wọnyi, kiyesi i, Angẹli Oluwa yọ si i loju orun, o sì wí fun u pe : Josefu, ọmọ Dafidi, máṣe bẹ̀ru lati mu Maria, aya rẹ, sọdọ

rẹ; nitori eyi ti a bí ninu rẹ, lati ọwọ́ Ẹmi-Mimọ́ wá ni. Ati on yio sì bí ọmọkọnrin kan, ti iwọ yio fi orukọ Jesu fun; nitori on ni yio gbà awọn enia rẹ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn.

Ifitọrẹ. Otitọ ati ànu mi yio wà pẹlu rẹ, ao sì gbé agbara rẹ ga nipa orukọ mi.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, a fi ijọsin wa fun ọ, a sì nfi irẹlẹ ọkàn bẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki o lè wù ọ lati mà pa ẹbun rẹ mọ́ ninu wa nipa ẹbẹ ti Josefu mimọ́, ọkọ iyá ọmọ rẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa, li ọdún mimọ́ ẹniti awa nrú ẹbọ iyin si ọ; nipasẹ Jesu-Kristi kannà Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Josefu, ọmọ Dafidi, máṣe bẹ̀ru lati mu Maria, aya rẹ, sodọ rẹ; nitori eyi ti a bí ninu rẹ̀, lati ọwọ́ Ẹmi-Mimọ́ wá ni.

Adura lẹhin komunioni.

Olorun alânu julọ, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ràn wa lọwọ́, ki o sì fiyesi i nipa ẹbẹ Josefu mimọ́, onijẹwọ́ rẹ, lati mà pa ẹbun rẹ nà mọ́ ninu wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ́ IJIṢẸ́ ANGELI FUN MARIA WUNDIA MIMỌ

Li ọjọ́ 25ⁿ ti oṣù Marṣi

Ipileṣẹ ti Misa. Gbogbo awọn olorò ninu

awọn enia yio mà bẹ̀bẹ ojurere rẹ. Awọn wundia ti yio tọ̀ ọ lẹhin li a o mu tọ̀ Ọba wá ; pẹlu inudidùn ati ayọ̀ li a o sì fi mu awọn aladugbo rẹ̀ tọ̀ Ọ wá. *Ps.* Ọkàn mi nsọ òrọ rere jade, ogo Ọba li emi nkọ orin mi sí. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o ti fẹ̀ ki Ọrọ rẹ di ara ninu Maria Wundia alabukún fun gẹgẹ bi òrọ Angẹli kan, fifun awa ti mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, pe bi awa ti gbagbọ́ pe Iyá Ọlọrun nitọ̀tọ ni on iṣe, ki a lè ri iranlọwọ́ gbà lọdọ rẹ nipa ẹ̀bẹ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Isai 7).

Li ojọ́ wọnyi ni Oluwa sọ fun Akasi pe : Bère lọwọ́ Oluwa Ọlọrun rẹ lati fi àmi kan hàn fun ọ ibaṣe ni ibú tabi lòke orun. Akasi sì dahùn wipe : Emi kì yio bère àmi kan, bẹ̀ni emi kì yio sì dán Oluwa wò. Isai sì wipe : Ẹ gbọ́ nisisiyi, enyin arale Dafidi : kò ha ti to fun nyin lati mà yọ enia lẹnu, ti enyin tún fi nyọ Ọlọrun mi lẹnu pẹlu bí? Nitorinà Oluwa tikalarẹ̀ ni yio fun nyin li àmi kan : kiyesi i, Wundia kan yio lóyun, yio sì bí ọmọkọnrin kan, ao sì pè orukọ rẹ̀ ni Emanueli. Ori-amu ati oyin ni on yio mà je, ki o lè mọ̀ lati kọ̀ ohun buburu silẹ, ati lati yàn ohun rere.

Gradual. A dà ôre-ọfẹ si ọ li ẹnu ; nitorinà ni Ọlọrun mbukún fun ọ lailai. Nitori otitọ, ìwa tutù ati ododo rẹ, li ọwọ́ ọtún rẹ yio mu ọ ṣe iṣẹ iyanu nlanla.

Traktu. Fetisi, ọmọbirin mi, ṣijuwò, ki o sì dẹ etí rẹ silẹ, nitoriti ẹ̀wa rẹ wù Ọba gidigidi. Gbogbo awọn ọlọrọ̀ ninu awọn enia mbẹ̀bẹ ojurere rẹ; awọn ọmọbirin awọn ọba yio sì mà bọlá fun ọ. Awọn wundia ti yio tọ̀ ọ lẹhin li ao mu tọ̀ Ọba wá; awọn aladugbo rẹ̀ li ao mu tọ̀ ọ wá; pẹlu inudidùn ati ayọ̀ li ao fi mu wọn wá, nwọn o sì wọ̀ âfin Ọba lọ.

(Lẹhin ojọ́ Ajinde Jesu-Kristi, lipò Graduali *ati* Traktu, *a wí eyiti o tẹle yi).*

Alleluia, alleluia. Mo kí ọ, Maria, o kún fun ôre-ọfẹ; Oluwa mbẹ̀ pẹlu rẹ, alabukún fun ni iwọ ninu awọn obirin. Alleluia. Ọpá Jesse ti ruwé nitòtọ, Wundia kan ti bí ọmọkọnrin kan ti iṣe Ọlọrun; Ọlọrun ti fun ni li alafia, o sì dà ohun irẹlẹ pọmọ́ eyiti o tobi ninu rẹ̀. Alleluia,

Ihin rere (Luk. 1, 26).

O ri gegẹ bi ti Rosario mimọ́ julọ ti Maria Wundia. (wò apa 317).

Ifitọrẹ. Mo kí ọ, Maria, o kún fun ôre-ọfẹ; Oluwa mbẹ̀ pẹlu rẹ; alabukún fun ni iwọ ninu awọn obirin.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fi ẹṣẹ̀ awọn ọrọ ijinlẹ ti igbagbọ́ tôtọ mulẹ ninu ọkàn wa, ki awa ti o jẹwọ pe Ọmọ rẹ ti a lóyun ninu Wundia kan li Ọlọrun tôtọ ati enia tôtọ, lè yẹ nipa agbara Ajinde igbalà rẹ̀ lati de ibi alafia aini-

pẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi, kannâ Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Wundia kan yio loyún, yio sì bí ọmọkọnri kan, ao sì pè orukọ rẹ̀ ni Emanueli.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, tú ôre-ọfẹ rẹ sinu ọkàn wa, ki awa ti o ti mọ Isọdienia ti Jesu-Kristi Ọmọ rẹ nipa isẹ riran ti Angẹli kan, lè de ibi ogo ajinde rẹ̀ nipa itoye agbelebu ati ijiyà rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi kannâ Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ JOHANU-BAPTISTA MIMỌ

Li ọjọ́ 24ⁿ ti osù Juni.

Ipilẹsẹ ti Misa. Lati inu iyá mi wá ni Oluwa ti dá orukọ mi, O sì ti ṣe ẹnu mi bi idà mimú ; labẹ ojiji ọwọ́ rẹ̀ li o ti dâbobo mi, o sì ṣọ mi di ọfà ti a ti yàn. *Ps.* Ohun rere ni lati mâ yìn Oluwa ati lati mà kọrin si ogo orukọ rẹ̀, Ọgá-ogo. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Olọrun. Iwọ ti o ti ṣọ ọjọ́ yi di ọlọlá fun wa nipa ibí Johanu mimọ́, fun awọn enia rẹ̀ li ôre-ọfẹ lati yọ̀ ninu ohun ti ẹmí, ki o sì dàri ọkàn awọn onigbagbọ́ rẹ̀ si ọ̀na igbalà ainipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Isai XLIX, 1).

E gbọ́ ti emi, ẹnyin erekùsu, ki ẹ sì fi etí silẹ, ẹnyin orilẹ ède ti òkèrè. Oluwa ti pè mi lati inu iyá mi wá, lati inu iyá mi wá li O ti ranti orukọ mi. O sì ti ṣe ẹnu mi bi idà mimú; labẹ ojiji ọwọ́ rẹ̀ li O ti dàbobo mi, O sì ṣọ mi di ọfà ti a ti yàn; ninu apó rẹ̀ li o ti pa mi mọ́. O sì wí fun mi pe: Iwọ ni iranṣẹ mi, Israeli, nitori ninu rẹ̀ li emi o ṣogo. Ati nisisiyi ni Oluwa wí fun mi, ẹniti o mọ mi lati inu iyá mi wá lati ṣe iranṣẹ rẹ̀, pe: Kiyesi i, mo ti yàn ọ lati ṣe imọlẹ awọn keferi, ki iwọ ki o lè ṣe igbalà mi titide opin aiye. Awọn ọba yio ri ọ, awọn ọmọ-alade yio sì dide, nwọn yio sì foribalẹ fun ọ nitori Oluwa ti iṣe olòtọ́, ati nitori Ẹni-Mímọ́ Israeli, ti o ti yàn ọ.

Graduali. Emi ti mọ ọ ki emi to dá ọ ninu iyá rẹ, ki iwọ ki o sì to ti inu rẹ̀ jade wá li emi ṣọ ọ di mimọ́. Oluwa sì nà ọwọ́ rẹ̀, o fi ba ẹnu mi, o sì wí fun mi pe: Ọmọ, Wòli Ogá-ogo li ao mâ pè ọ, nitori iwọ ni yio ṣâju Oluwa lati tún ọ̀na rẹ̀ ṣe.

Illin rere (Luk. I, 57).

Nigbati akokò Elisabeti pé ti yio bi, O bi ọmọkọnri kan. Awọn aladugbo, ati awọn arà rẹ̀ sì gbọ́ pe Oluwa ti ṣe ãnu nla fun u, nwọn sì ba a yọ̀. O sì ṣe, ni ijọ́ keje nwọn wá lati kọ ọmọ nâ nilà, nwọn sì pè e ni Sakaria, gegẹ bi orukọ baba rẹ̀. Iyá sì dahùn wipe: Bẹ̀kọ, ṣugbọn Johanu li ao pè e. Nwọn sì wí fun u

pe : Kò si ọkan ninu awọn ará rẹ ti a npè li orukọ yi. Nwọn sì fi apẹrẹ bère lọwọ baba rẹ bi o ti nfẹ ki a pè e. O sì bère walà, o sì kọ ọrọ wọnyi si i pe : Johanu li orukọ rẹ. Ẹnu sì yà gbogbo wọn. Ẹnu rẹ ṣi lojukannà, okùn ahọn rẹ sì tú, o sì sọrọ, o sì yìn Ọlọrun. Ẹru sì bà gbogbo awọn aladugbo wọn, okiki gbogbo nkan wọnyi sì kàn ká gbogbo ilẹ òke Judea. Gbogbo awọn ti o ti gbọ nkan wọnyi sì pa wọn mọ li ọkàn wọn, nwọn sì wipe : Irú ọmọ wo ni eyin nrò pe yio jẹ ? Nitoriti ọwọ Oluwa ti mbẹ pelu rẹ. Sakaria, baba rẹ, sì kún fun Ẹmi-Mimọ, o sì sọ tele wipe : Ibukún ni fun Oluwa, Ọlọrun Israeli, nitoriti o ti bẹ awọn enia rẹ wò, ti o sì ti da wọn nidè.

Ifitọrẹ. Olododo yio gbà bi igi ọpẹ, yio sì dàgba bi igi sedari ni Libanoni.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa nrú èbun yi si ọ lori altari rẹ lati bọlá bi o ti yẹ fun ibi èniti o ti sọ wiwá Olugbala araiye tele, ti o sì ti fi Jesu-Kristi, Ọmọ rẹ, Oluwa wa, hàn fun wa nigbati O de; nipasẹ Jesu-Kristi kannà Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ọmọ, woli Ọgá-ogo li ao mà pè ọ, nitori iwọ yio ṣàju Oluwa lati tún ọna rẹ ṣe.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki ijọ awọn enia rẹ ki o mà yọ nitori ibi Johanu-Baptista mimọ, nipa èniti a ti mọ Olorisun atunbí wa; nipasẹ Jesu-Kristi kannà Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ ỌDUN TI AWỌN APOSTOLI PITERU ON PAULU MIMỌ

Li ọjọ́ 29ⁿ ti oṣù Juni

Ipilẹṣẹ ti Misa. Nisisiyi ni mo to mọ́ nitôto pe Oluwa ti rán Angẹli rẹ̀, o sì gbà mi là lọwọ́ Herodu, ati kuro ninu gbogbo ireti awọn enia Ju. *Ps.* Oluwa, iwọ ti dán mi wò. iwọ sì ti mọ́ mi; iwọ mọ́ ijoko ati idide mi. Ogo ni fun Baba, etc

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o ti sọ ọjọ́ oni di mimọ́ nipa ikú nitori igbagbọ́ ti awọn Apostoli rẹ Peteru on Paulu mimọ́, fi ôre-ọfẹ fun ijọ awọn enia rẹ, pe bi o ti ri igbagbọ́ gbà lọwọ́ wọn, bẹ̀ gẹgẹ ni ki o lè mà tẹle ẹkọ́ mimọ́ wọn li ohunkohun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iṣe Apostoli xii, 1).

Li akokò ìgba nâ ni Herodu nawọ́ rẹ̀ lati ṣe inunibini si awọn kan ninu ijọ awọn kristiani, o sì mu ki a fi idà bẹ́ Jakọbu, arakọnri Johanu, lori. Nigbati o sì ri pe, o dùnmọ́ awọn Ju o tubò mu Peteru pẹlu. Nigbanâ li ọjọ́ àkara alaiwú. Nigbati o ti mu u, o fi i sinu tubu, o sì fi i ṣọ́ iṣọ́ ẹgbẹ́ mẹrin, ti ọkọkan ni ọmọ-ogun mẹrin, nitori o ngbèro lati pa a niwaju gbogbo awọn enia lẹhin ajọ Irekọja (Paska). Niwọn igbati nwọn pa Peteru mọ́ bayi ninu tubu, ijọ awọn kristiani ngbadura fun u laisimi si Ọlọrun. Ṣugbọn li oru

nâ ti o ṣâju ọjọ́ ti Herodu ti yàn fun ikú rẹ̀, Peteru nsùn lârin awọn ọmọ-ogun meji, ni tifi ẹ̀wọn meji dè e, awọn iṣọ́ ti o wà niwaju ilẹkun sì nṣọ́ tubu nâ. Sì kiyesi i, Angẹli Oluwa duro tì i, tubu nâ sì kún fun imọlẹ. Nigbanâ ni Angẹli nâ lù Peteru li ẹgbẹ pẹpẹ, o sì jí i, o wipe : Dide kánkan. Awọn ẹ̀wọn sì bọ silẹ kuro li ọwọ́ rẹ̀, Angẹli nâ sì wí fun u pe : Di àmure, ki o sì wọ̀ bàta rẹ. O sì ṣe bẹ̀, o tún wí fun u pe : Dà aṣọ rẹ bora, ki o sì mâ tọ̀ mi lẹhin. Peteru sì jade, o ntọ̀ ọ lẹhin lọ, kò sì mọ̀ bi otitọ li ohun nâ ṣe lati ọwọ́ Angẹli nâ wá, ṣugbọn o ṣebi on wà li ojuran. Nigbati nwọn ti koja iṣọ́ kini ati keji, nwọn de ẹnu ọ̀na ilẹkun irin, ti o ja si ilú ; ti o sì tikalarẹ̀ ṣí silẹ fun wọn ; nwọn sì jade, nwọn sì nlọ li eti ọ̀na igboro kan, lojukannâ Angẹli nâ sì fi i silẹ lọ. Nigbanâ ni oju Peteru walẹ, o sì wí pe : Nigbayi ni mo to mọ̀ nitõtọ pe Oluwa ti rán Angẹli rẹ̀, o sì gbà mi là lọwọ́ Herodu, ati kuro ninu gbogbo awọn enia Ju.

Graduali. Iwọ o mâ fi wọn jẹ ọmọ-alade lori ilẹ gbogbo. Nwọn o mâ ranti orukọ rẹ, Oluwa. A ti bí awọn ọmọ fun ọ, awọn ti yio rọ̀po awọn baba rẹ ; nitorinâ ni awọn enia yio ṣe mâ yìn Ọ lai ati lailai. Alleluia, alleluia. Iwọ ni Peteru, ati lori apata yi li emi o kọle Eklesia mi si. Alleluia.

Ihin rere (Mat. xvi, 13).

Nigbati Jesu de igberiko ilú Sesarea ti Filippi, o bi awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ lère, wipe : Tani awọn

enia nfi Ọmọ-enia pè? Nwọn sì da a lohùn wipe: Awọn omiran wipe Johanu-Baptista ni iwọ; awọn ẹlomî wipe Elia ni; awọn ẹlomiran wipe Jeremia, tabi ọkan ninu awọn Woli ni. Jesu wí fun wọn pe: Ṣugbọn tani enyin nfi mi pè? Nigbanâ ni Simoni Peteru dahùn wipe: Kristi, Ọmọ Ọlọrun alâye ni iwọ ise. Jesu sì da a lohùn wipe: Alabukún fun ni iwọ, Simoni, ọmọ Jona, nitori kì ise eran ara, ati ẹjẹ li o.fi eyi hàn ọ, ṣugbọn bikose Baba mi ti mbẹ li ọrun. Emi pẹlu sì wí fun ọ pe: Iwọ ni Peteru, ati lori apata yi li emi o kọle Eklesia mi si, agbara oju ọna ọrun apadi ki yio sì lè bori rẹ; Emi o sì fun ọ ni awọn kọkọrọ ijọba ọrun, ati ohunkohun ti iwọ ba dè li aiye, ao sì dè e li ọrun. ati ohunkohun ti iwọ ba tú li aiye, ao sì tú u li ọrun.

Ifitọrẹ. Iwọ o mà fi wọn jẹ ọmọ-alade lori ilẹ gbogbo; nwọn o mâ ranti orukọ rẹ, Oluwa, lati irandiran.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki adura awọn Apostoli rẹ ki o sìn ẹbọ ti a yà sì mimọ́ fun orukọ rẹ yi lọ, ki o sì fifunni, ki a lè ri idariji èsẹ wa ati âbo rẹ gbà nipa rẹ nâ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa, Amin.

Komunioni. Iwọ ni Peteru, ati lori apata yi li emi o kọle Eklesia mi si.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, nipa ẹbẹ awọn Apostoli rẹ mâ pa

gbogbo awọn ti iwọ fi onjẹ orun bọ mọ kuro ninu gbogbo ipọnju ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ IBÈWO TI MARIA WUNDIA MIMỌ SI ELISABETI MIMỌ

Li ọjọ 2i ti oṣù Juli.

Ipilẹṣẹ ti Misa. A kí ọ. Iyá mimọ́, iwọ ti o bí Ọba, ẹniti o nṣakoso orun ou aiye lai ati lailai. *Ps* Ọkàn mi nsọ òro rere jade. ogo Ọba li emi nkọ orin mi si. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fiyesi i lati fi ẹ̀hun ôre-ọfẹ rẹ orun fun awọn ọmọ-ọdọ rẹ, pe bi ibímọ ti Maria Wundia alabukún fun ti jẹ ipilẹṣẹ igbalà wa, bẹ̀ gẹgẹ ni ki a lè ri ipòsi alafia gbà li ọjọ́ mimọ́ ti ibẹ̀wo rẹ̀ si ará rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Orin Sal. 2).

Sawò o, O mbọ̀, o nfò lori awọn òke nla, o sì nkoja lori awọn òke kekeké. Olufẹ mi dabi egbin ati ọmọ agbọnrin. Sawò o, o duro lẹhin ogiri wa ; o yọju lori ferese, o fara rẹ̀ hàn loju ferese ọlọnà. Sawò o, olufẹ mi wi fun mi pe : Dide kánkan, ifẹ mi, àdaba mi, arẹ̀wa mi ; ki o sì wá. Nitori igba otutù ti koja, òjo ti dá, o sì ti lọ. Awọn itanná eweko yọ jade lori ilẹ wa. Akokò irẹ̀gililọwọ́ ti de, a sì gbọ́ ohùn oderekoko ni ilẹ wa : igi ọpọtọ ti so eso titun rẹ̀ ;

awọn àjara tanná, nwọn sì rán ôrun didùn jade. Dide, ifé mi, arẹ̀wa mi, ki o sì wá. Adaba mi, iwọ ti o wà ninu pàlapala okuta, ati ninu ihò ogiri, fi oju rẹ hàn fun mi, ki o sì jẹ ki emi gbọ́ ohùn rẹ; nitori didùn ni ohùn rẹ, oju rẹ sì lẹ̀wa.

Graduali. Alabukún fun ni iwọ, iwọ sì yẹ fun ọlá, Maria Wundia, iwọ ti o di iyá Olugbala wa laiṣọ ìwa wundia rẹ nù. Wundia Iyá Ọlọrun, Ẹniti gbogbo ilẹ aiye kò lè gbà, o há ara rẹ mọ́ ninu rẹ bi enia. Alleluia, alleluia. Alabukún fun ni iwọ, Maria Wundia mimọ́, iwọ sì yẹ fun gbogbo iyìn, nitori Jesu-Kristi, Ọlọrun wa, ôrun ododo ti inu rẹ jade wá. Alleluia.

Ihin rere (Luk. i. 39.)

Nigbanâ ni Maria dide, o lọ kánkan si ilẹ òke, sì ilú kan ni Juda. O sì wọ ile Sakaria lọ, o sì kí Elisabeti; o sì ṣe, nigbati Elisabeti gbọ́ ikí Maria, ọmọ ṣọ ninu rẹ̀, Elisabeti sì kún fun Emi-Mimọ́, o sì kigbe li ohùn rara, o sì wipe: Alabukún fun ni iwọ ninu awọn obirin, alabukún fun sì ni eso inu rẹ. Nibo sì li alafia yi ti wá ba mi, ti iyá Oluwa mi fi tọ mi wá? Nitori lojukannà ti ohùn ikí rẹ ti bọ si mi leti, ọmọ ṣọ ninu mi fun ayọ̀. Alabukún fun sì ni iwọ ti o gbagbọ́, nitori gbogbo nkan wọnyi ti a ti ṣọ fun ọ lati ọdọ Oluwa wá yio ṣẹ.

Ifitọrẹ. Alabukún fun ni iwọ, Maria Wundia, ti o gbé Ẹlẹdá ohun gbogbo; ti o sì bí Ẹlẹdá rẹ, ti o sì jẹ Wundia titilai.

Adura ti a kà jẹ́ẹ́.

Oluwa, jẹ́ ki a ràn wa lọ́wọ́ nipa ìwa enia ti Ọmọ bibí rẹ́ nikanṣoṣo, pe bi Jesu-Kristi Oluwa wa, nigbati a bí i lati inu Wundia kan wá, kò ti bà ìwa wundia ti iyá rẹ́ jẹ́, ṣugbọn o yà a si mimọ́, bẹ́ gẹ́gẹ́ ni ki o lè gbà wa kuro ninu ẹ̀ṣẹ́ wa li ọjọ́ mimọ́ ti Ibẹ̀wò Maria si arán rẹ́, ki o sì sọ ẹ̀bọ wa di atẹ́wọ́gbà fun Ọ; nipasẹ́ Jesu-Kristi kannâ Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Alabukún fun ni inu Maria Wundia, ti o gbé Ọmọ Baba aiyeraiye.

Adura lẹ́hin komunioni.

Oluwa, awa ti gbà ẹ̀bun mimọ́, ti awa ti rú si Ọ li ọjọ́ ọdún mimọ́ yi ti a nṣe lọ́dọ́dún, fifunni, awa mbẹ̀bẹ̀ lọ́dọ́ rẹ́, ki o lè gbà ohun irúlarada wọnyi fun wa, ti a nṣe alaini nisisiyi ati li aiye ti mbọ̀; nipasẹ́ Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ IBÍ MARIA WUNDIA ALABUKUN FUN

Li ọjọ́ 8° ti oṣù Septemberi.

Misa ri gẹ́gẹ́ bi ti Ibẹ̀wo, *bikoṣe iyàtọ ti fifi òrọ* Ibí *sipò ti* Ibẹ̀wo Maria si arán rẹ́ (366).

Epistoli ri gẹ́gẹ́ bi ti ọjọ́ ti a lóyun Maria Wundia laibawọ́n ẹ̀ṣẹ́ ahọ́ṣẹ́ (350), *ati Ihin rere bi ti Joakimu mimọ́* (306).

ỌJỌ TI ORUKỌ MIMỌ TI MARIA

Li ijọ́ ọsẹ lẹhin ọjọ́ Ibí rẹ̀

Ipilẹṣẹ ti Misa ri gẹgẹ bi ti ọjọ́ Ijisẹ Angẹli fun Maria.

Adura

Olọrun Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, lifunni, ki awọn onigbagbọ́ rẹ, ti nyọ̀ niti orukọ ati âbo ti Maria Wundia mimọ́, ki o lè bọ kuro ninu ewu ati gbogbo ibi li aiye yi nipa ẹ̀bẹ rẹ̀, ki nwọn ki o sì lè yẹ lati ri alafia ainipẹkun gbà li ọrun rere; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ekles. XXIV, 23).

Gẹgẹ bi àjara li emi so eso olórùn didùn, itanná mi sì jẹ eso ti ogo ati ti ọlá. Emi ni iyá ti itẹ́ ti o l'ẹ̀wa, ti ibẹ̀ru, ti ọgbọ́n, ati ti ireti mimọ́. Ninu mi ni gbogbo ôre-ọfẹ ti ọ̀na ati ti otitọ wà; ninu mi ni gbogbo ireti ti ìye ati ti ìwa rere wà. Ẹ wá sodọ mi, gbogbo ẹnyin ti nṣe afẹri mi, ki ẹ sì kún fun eso mi; nitori ẹmí mi dùn jù oyin lọ. ati ijogún mi dùn jù oyin ati afara oyin lọ. Iranti orukọ mi yio duro lai ati lailai. Awọn ti o ba jẹ mi, ebi yio mâ pa wọn nigbagbogbo, awọn ti o ba sì mu mi, ongbẹ yio mâ gbẹ wọn nigbagbogbo; ẹniti o ba gbọ́ ti emi, oju kì yio tì i, ẹniti ba sì ṣe iṣẹ rẹ̀ nipa mi, kì yio dẹ̀ṣẹ. Ẹniti o ba fi mi mọ́ fun ẹlomiran, yio ri iye ti kò nipẹkun gbà.

Graduali O ri gẹgẹ bi ti Ibẹwò ti Maria-Mimọ́ si ará rẹ̀ *titide* Alleluia, alleluia. Iwọ ti jẹ wundia mimọ́ sibẹ̀sibẹ̀ lẹhin ibímọ rẹ ; bẹ̀bẹ̀ fun wa, Iyá Ọlọrun.

Ihin rere.

O ri gẹgẹ bi ti Rosaria mimọ́ julọ ti Maria Wundia. (wò apa 317.).

Ifitọrẹ. Mo kí ọ, Maria, *titide ọrọ* Jesu.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, nipasẹ ânu rẹ ati nipa ẹbẹ Maria Wundia mimọ́ jẹ ki ọrẹ-ẹbọ yi ki o lè gbà âsiki ati alafia fun wa nisisiyi ati titi aiye ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Alabukún fun ni inu Maria Wundia, ti o gbé Ọmọ Baba aiyeraiye.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, bi awa ti ri iranlọwọ́ ti igbalà wa yi gbà, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, tifunni, ki a lè mâ dâbobo wa nipa âbo Maria mimọ́, fun ọlá ẹniti awa ti rú ẹbọ yi si Ọlá nla rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ TI AWỌN ẸDUN MEJE TI MARIA WUNDIA MIMỌ

Li ijọ́ ọsẹ kẹta ti oṣù Septemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Lẹba agbelebu Jesu ni iyá rẹ̀, ati arabirin iyá rẹ̀, Maria, aya Kleofa, ati Salome, ati Maria Magdalene duro. Jesu sì wí pe : Obirin, wò ọmọ rẹ, ati fun ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Wò iyá rẹ. Ogo ni fun Baba.

Adura.

Ọlọrun, ni ijiyà ẹniti, gẹgẹ bi Simeoni ti sọ tẹlẹ, idà ti ẹdùn gún Maria iyá ati Wundia ologo li ọkàn, ti o kún fun ifẹ ; nipa ânu rẹ fifunni, ki awa ti o nṣe iranti ẹdùn rẹ̀ ki o lè ri eso ijiyà rẹ gbà : Iwọ ti o wà, ti o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba ninu isọkan Ẹmi-Mimọ, lai Ọlọrun kan, aiye ainipẹkun Amin

Epistoli (Judith XIII, 22).

Oluwa ti bukún fun ọ nipa agbara rẹ ; nitori nipa rẹ li O ti pa awọn ọtá wa run. Ọmọbirin. iwọ li ẹniti Ọlọrun ọgá ogo ti bukún fun jù gbogbo awọn obirin ti mbẹ li aiye lọ. Ibukún ni fun Oluwa ti o dá ọrun on aiye, nitori li ọjọ oni li O ti sọ orukọ rẹ di olokiki tobẹ, ti iyin rẹ kì yio kuro li ẹnu awọn enia, ti yio mâ ranti agbara Oluwa lai ati lailai, nitoriti iwọ kò dá ẹmí rẹ si, nigbati iwọ ri isẹ ati ipọnju awọn enia rẹ, ṣugbọn iwọ ti da iparun wa duro niwaju Ọlọrun wa.

Graduali. Maria Wundia, iwọ duro lẹba agbelebu Jesu, Ọmọ rẹ, Olugbalà wa, ti on ti ibanujẹ ati isọkún. Maria mimọ, ayaba ọrun ati Iyálode aiye ti nduro lẹba agbelebu Oluwa wa Jesu-Kristi ti on ti ifajuro. Gbogbo ẹnyin ti nkọja li ọna yi, ẹ wò, ki ẹ sì ri bi ibanujẹ kan ba wà bi ibanujẹ mi.

Orin Stabat Mater dolorosa etc. (321).

Ihin rere (Joh XIX, 25).

Nigbanâ ni Iyá Jesu, ati arabirin iyá Rẹ, Maria, aya Kleofa, ati Maria Magdalene duro lẹba agbelebu. Nigbati Jesu ri iyá Rẹ, ati lẹba rẹ ọmọ-ẹhin nâ ti On fẹ, o wí fun iyá Rẹ pe : Obirin, wò Ọmọ rẹ. Lẹhinnâ O wí fun ọmọ-ẹhin nâ pe : Wò iyá rẹ. Lati wakati nâ lọ li ọmọ-ẹhin nâ ti gbà a si ile rẹ.

Ifitọrẹ. Wundia, Iyá Ọlọrun, nigbati iwọ ba duro niwaju Oluwa, ranti lati sọrọ wa ni rere fun U, ati lati yí ibinu rẹ kuro lori wa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa Jesu-Kristi, awa nrú adura ati ẹbọ wa si Ọ, ni fifi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ, pe bi awa ti nranti ninu adura wa ti ẹdùn nâ ti o gún Maria iyá rẹ mimọ li ọkàn gẹgẹ bi idà, bẹ gẹgẹ ni nipa ẹbẹ rẹ ati ti awọn ẹgbẹ mimọ rẹ ti mba a duro lẹba agbelebu, ki a lè jẹ alabapin ninu ère awọn Enia mimọ, nipasẹ itoye ikú rẹ : Iwọ ti o wà, t'o sì njọba, etc.

Komunioni. Alabukún fun li ara Maria Wundia mimọ́, ti o ri ọlá ti ikú nitori igbagbọ́ gbà lẹba agbelebu Oluwa laikú ikú.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa Jesu-Kristi, ẹ̀ ki ẹbọ ti awa ti ẹ̀ alabapin li ọjọ́ oni, ti a nfi ifọkansìn ṣe iranti ilujá ti ọkàn iyá rẹ̀ wundia, ki o lè gbà gbogbo ohun rere ati igbalà ainipẹkun fun wa lọdọ ânu rẹ̀ : Iwọ ti o wà, ti o sì njọba etc.

IYIPADA TI APOSTOLI PAULU MIMỌ

Li ọjọ́ 25ⁿ ti oṣù Januari.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Mo mọ̀ ẹniti emi gbagbọ́, o sì da mi loju pe on lagbara to lati pa ohun ti mo fi le e lọwọ́ mọ́ titidi ọjọ́ ni, bi onidajọ ododo. *Ps.* Oluwa, iwọ ti dán mi wò, iwọ sì ti mọ̀ mi : iwọ mọ̀ ijoko ati idide mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun, Iwọ ti o ti kọ́ gbogbo aiye li ẹkọ́ rẹ̀ nipasẹ̀ iwàsu Apostoli Paulu mimọ́, fi ôre-ọfẹ́ fun wa, ki awa ti o nṣe iranti iyipada rẹ̀ li ọjọ́ oni, ki o lè de ọdọ rẹ̀ nipa titọpasẹ̀ apẹrẹ rẹ̀ ; nipasẹ̀ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iṣe Apost. IX, 1).

Li ọjọ́ wọnyi ni Saulu, ẹniti o nmí ibinu ati

pipa si awọn ọmọ-ẹhin Oluwa, tọ olori awọn alufa lọ, o si bère iwe lọwọ rẹ fun ijọ enia awọn Ju ni Damasku pe, bi on ba ri awọn okọnri ati obirin kan ti ise ti irú ẹgbẹ nà, ki o le mu wọn ni didè wá si Jerusalemu. Bi o si ti nlọ, ti o si ti sunmọ eti Damasku, imọlẹ mọ yi i ka lojiji lati ọrun wá. O ṣubu lulẹ, o si gbọ ohùn kan ti o wi fun u pe : Saulu, Saulu. èse ti iwọ fi nse inunibini si mi ? On si wi pe : Tani iwọ, Oluwa ? Oluwa si dahùn wi pe : Emi ni Jesu, ẹniti iwọ nse inunibini si : o soro fun ọ lati tapá si ẹgún. Nigbanà ni o fi iwariri ati iyanu wipe : Oluwa, kini iwọ nfẹ ki emi ki o se ? Oluwa si wi fun u pe : Dide, ki o si lọ si ilú nà, nibẹ li ao so fun ọ li ohun ti iwọ o se. Ṣugbọn awọn okọnri ti mbá a rìn pọ duro ti awọn ti iyanu, nwọn ngbọ ohùn, ṣugbọn nwọn kò ri ẹnikan. Saulu si dide ni ilẹ, nigbati o si si oju rẹ, kò ri ẹnikẹni. Nigbanà ni nwọn fà a lọwọ, nwọn si mu u lọ si Damasku, nibiti o gbé fun ijọ meta lairiran, kò si je, bẹni kò si mu. Ọmọ-ẹhin kan si wà ni Damasku, ti a npè ni Anania ; on li Oluwa wi fun li ojuran pe : Anania. O si dahùn wipe : Wò o, emi ni yi, Oluwa. Oluwa si wi fun u pe : Dide, ki o si lọ si ita ti a npè ni Oganran, ki o si bère enikan ti a npè ni Saulu, ará Tarsu, ni ile Judasi, sá kiyesi i, o ngbadura. (Saulu si ti ri okọnri kan li ojuran, ti a npè ni Anania, ti o wọle, ti o si fi ọwọ rẹ le e, ki o le riran). Anania si dahùn wipe : Oluwa, mo ti gburó okọnri yi lọdọ ọpọlọpọ enia, niwọn bi o ti se buburu to si awọn enia rẹ mimọ ni Jerusalemu. O si gbà ase lati ọdọ awọn olori alufa wá si

ihinyi, lati dè gbogbo awọn ti npè orukọ rẹ lẹwọn. Oluwa sì wí fun u pe : Mà lọ, nitoriti ọkọnri yi ișe ohun-èlo ti a ti yàn fun mi, lati mu orukọ mi lọ siwaju awọn keferi, awọn ọba ati awọn ọmọ Israeli. Nitori emi o fihàn a niwọn bi yio ti jiyà to nitori orukọ mi. Anania sì mu ọna rẹ̀ pọ̀n, o sì wọ̀ inu ile nà o ti ọwọ́ rẹ̀ le e, o sì wí fun u pe : Saulu, Arakọnri mi, Oluwa Jesu. ti o farahàn ọ li ọna bi iwọ ti mbọ̀wá, li o rán mi ki iwọ ki o lè riran, ki o sì lè kún fun Ẹmi-Mimọ́. Lojukannà ohun kan bọ kuro li oju rẹ̀ bi ipẹ́pẹ́, o sì riran, o dide, a sì fun u li ibatisi. Nigbati o sì ti jẹun, ara rẹ̀ le; o sì bá awọn ọmọ-ẹhin ti o wà ni Damasku duro fun ijọ melokan. Lojukannà o sì wàsu ni ile apejọ awọn Ju pe Jesu li Ọmọ Ọlọrun. Ẹnu sì yà gbogbo awọn ti o ngbọ́, nwọn sì wipe : Ọkọnri yi ha kọ́ ni ẹniti o ti nșe inunibini si awọn ti npè orukọ yi ni Jerusalemu, ti o sì wà si ihinyi lati mu wọn ni didè lọ fifun awọn olori alufa bi? Ṣugbọn agbara Saulu pọ̀ si i, o si dojuti awọn Ju ti o wà ni Damasku, nipa fifihàn wọn pe Jesu ni Kristi nà.

Graduali. Ẹniti o șișẹ aitase ninu Piteru lati ti i jẹ Apostoli, on kannà li o sì șișe ninu mi lati sọ mi di Apostoli awọn keferi ; nwọn sì mọ̀ ọre-ọfẹ Ọlọrun ti a fifun mi. Ore-ọfẹ Ọlọrun kò jẹ asan ninu mi, ṣugbọn o mà gbé inu mi nigbagbogbo. Alleluia, alleluia. Paulu ẹni mimọ́ nlanla, ohun-èlo ti a ti yàn, ẹ̀ fun ọlá nitôtọ, nitoriti o yẹ lati joko lori itẹ́ kejila. Alleluia.

(Lẹhin ijọ ọsẹ Septuagesima, lipò Alleluia, *etc., a wí eyiti o tẹle yi pe :)*

Iwọ ni ohun-èlo ti a ti yàn, Apostoli Paulu mimọ, iwọ ẹ fun ọlá nitòtọ. Iwọ ni Oniwàsu otitọ, ati Olukọ awọn keferi li igbagbọ ati li otitọ. Nipa rẹ li awọn keferi ti mọ ôre-ọfẹ Ọlọrun. Bẹbẹ fun wa lodọ Ọlọrun, ẹniti o ti yàn ọ.

Ihin-rere (Mat. XIX, 27).

Nigbanà ni Piteru wí fun Jesu pe : Wò o, awa ti fi ohun gbogbo silẹ, awa sì ntọ ọ lẹhin : Njẹ kini ère wa yio jẹ? Jesu sì wí fun wọn pe : Lòtọ ni mo wí fun nyin pe : Ẹnyin ti ẹ ntọ mi lẹhin, ni igba atumbi (ajinde gbogbo enia), nigbati Ọmọ-enia yio joko lori itẹ ogo rẹ, ẹnyin pẹlu o joko lori itẹ mejila, ẹnyin o sì mà ṣe idajọ awọn èya Israeli mejejila. Ati ẹnikẹni ti o ba fi ile rẹ silẹ, tabi arakọnri rẹ, tabi arabirin rẹ, tabi baba rẹ, tabi iyá rẹ, tabi ọmọ rẹ, tabi ilẹ rẹ nitori orukọ mi, yio ri ọrọrun gbà, yio sì jogún iye ti kò nipẹkun.

Ifitọrẹ. Ọlọrun, loju mi a ti sọ awọn ọrẹ rẹ di ọlọlá jojọ, a sì fi ẹsẹ ijọba wọn mulẹ gidigidi.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, sọ ọrẹ-ẹbọ awọn enia rẹ di mimọ nipa ẹbẹ Paulu Apostoli rẹ, ki ohun nâ ti o wù ọ nipa ìlana rẹ ki o lè jẹ atẹwọgbà julọ fun ọ nipa âbo ẹniti o mbẹbẹ fun wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Lôtọ ni mo wí fun nyin pe: ẹnyin ti o fi ohun gbogbo silẹ, ti o sì ntọ mi lẹhin, yio ri ọrọrun gbà, yio sì jogún ìye ti kò nipẹkun.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa ti a ti sọ di mimọ nipa Sakramenti igbalà rẹ mbẹbẹ lọdọ rẹ, tifunni, ki awa ki o máṣe rèhin ninu adura ẹniti iwọ fi wa le âbo rẹ lọwọ lati ṣe amọna wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ MARKU MIMỌ, EFANGELISTI.

AKỌWE IHIN RERE; *li ọjọ 25ⁿ Aprili.*

Ipilẹṣẹ ti Misa. Olọrun, iwọ dâbobo mi kuro ninu ìmọ ìkọkọ awọn oluṣe buburu, ati kuro ninu ọpọ awọn ẹlẹṣẹ. *Ps.* Olọrun, gbọ́ adura ti mo gbà si ọ; ki o si gbà ẹmí mi là kuro ninu ẹru awọn ọtá mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun, Iwọ ti o ti fi Marku Efangelisti mimọ rẹ je Oniwàsu Ihin rere rẹ, tifunni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki awa ki o lè mâ lọ siwaju ninu ìwa rere nipa ẹkọ́ rẹ, ki a si lè mà dâbobo wa nipa ẹbẹ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Esekieli I, 10).

Niti aworan oju awọn ẹdá alâye mẹrin, awọn mẹrẹrin ni oju enia, ati oju kiniu nìha ọtún ; awọn mẹrẹrin sì ni oju malu nìha osìn ; awọn mẹrẹrin sì ni oju idì lẹhìn. Oju wọn ati iyẹ wọn sì nà soke : iyẹ meji olukuluku wọn kàn ara wọn, meji sì bò ara wọn. Olukuluku wọn sì lọ lọkankan ganran. Nwọn sì lọ si ibikiti ti agbara Ẹmí ba gbà wọn lọ, nwọn kò sì yipada nigbati nwọn lọ. Aworan awọn ẹdá alâye nà, ati irí wọn dabi ọgunná ti njó, ati bi ìná fìtila. A ri ìná ti o mọlẹ, ti o lọ kakiri lârin awọn ẹdá alâye nà, manamaná sì jade lati inu ìná nà wá. Awọn ẹdá alâye nà sì sure, nwọn sì pada bi kikọ manamaná.

Graduali. Alleluia, alleluia. Awọn ọrun yio mà rohìn iṣẹ iyanu rẹ, Oluwa, a o sì mà yìn otitọ rẹ ninu awujọ awọn Enia mimọ. Alleluia, alleluia. Oluwa, Iwọ ti fi adé okuta iyebiye dé e ladé.

Ihin rere (Luk. x, 1).

Nigbanâ ni Oluwa tún yàn âdọrin ọmọẹhin miran, o sì rán wọn ni meji meji lọ siwaju rẹ si gbogbo ilú ati ibiti on tikalarẹ gbé fẹ lati de. O sì wí fun wọn pe : Ikorè pọ, sugbọn awọn alagbaṣe diẹ ni wọn. Nitorinà ẹ bẹ Oluwa ikorè, ki o lè rán awọn alagbaṣe sinu ikorè rẹ. Ẹ mâ lọ ; mo rán nyin lọ bi ọdọ-agutan sârin ikorikò. Ẹ máṣe mu àsuwọn, tabi oketè, tabi batà, ki ẹnyin ki o má sì ṣe kí ẹnikẹni li

ọna. Ni ilekile ti ẹnyin ba wọ, ẹ tète wipe: Ki alafia ki o wà fun ile yi. Bi ọmọ alafia ba mbẹ nibẹ, alafia nyin yio bà le e lori; ṣugbọn bi kò ba si, yio tún pada sori nyin. Ni ile kannâ ni ki ẹnyin ki o gbé, ẹ mâ je, ki ẹ si mâ mu ohunkohun ti nwọn ba ni; nitori alagbaṣe yẹ fun ọya rẹ. Ẹ máṣe ṣi lati ile de ile! Ati ni ilúkilú ti ẹnyin ba wọ, bi nwọn ba gbà nyin, ẹ je ohunkohun ti a o gbé kalẹ niwaju nyin; ki ẹ si mu awọn alarùn ti mbẹ ninu rẹ larada, ki ẹ wí fun wọn pe: Ijọba Ọlọrun kù si dède si nyin.

Ifitọrẹ. Awọn ọrun yio mâ rohìn iṣẹ iyanu rẹ, Oluwa, nwọn o si mâ yìn otitọ rẹ ninu awujọ awọn Enia mimọ.

Adura ti a kà jeje.

Ni rirú ẹbun wa si Ọ li ọjọ ọdún mimọ ti Marku Efangelisti mimọ rẹ, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, fifunni, pe bi iwâsu Ihin rere rẹ ti sọ ọ di ologo, bẹ gẹgẹ ni ki ẹbẹ rẹ ki o lè sọ wa di atewọgbà fun ọ ni òrọ ati iṣe; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni Olododo yio mâ yọ ninu Oluwa, yio si mâ gbẹkẹle e; gbogbo awọn olọkàn rere li a o si mâ yìn.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, je ki sakramenti mimọ rẹ ki o lè fun wa li iranlọwọ titilọ, ki o si lè mâ dàbobo wa nipa ẹbẹ Marku mimọ kuro ninu gbogbo ipọnju; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ LỌRENSU MIMỌ, MARTIRI.

Li ojọ́ 10a ti oṣù Augusti.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Iyìn ati ẹ̀wa li o wà niwaju rẹ̀, ìwa mimọ́ ati ọlá nla mbẹ ninu ibi mimọ́ rẹ̀ *Ps.* Ẹ kọrin titun si Oluwa, ẹ kọrin si Oluwa, gbogbo aiye. Ogo ni fun Baba.

Adura.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ràn wa lọwọ́ lati pana itẹkufẹ ara wa, iwọ ti o fi ôre-ọfẹ fun Lọrensu mimọ́ lati bori iná idalóro rẹ̀; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (2 Kor. IX, 6).

Ẹnyin ará mi, ẹniti o ba fúnrugbìn diẹ, diẹ ni yio sì ká; ẹniti o ba fúnrugbìn pupọ̀, pupọ̀ ni yio sì ká. Ki olukuluku ki o da ówo gẹgẹ bi o ti pinnu li ọkàn rẹ̀, kì iṣe pẹlu ifajuro ati afipáṣe, nitori Ọlọrun fẹ̀ ọlọrẹ̀ oninudidùn. Ọlọrun sì lagbara to lati kún nyin fun gbogbo ôre-ọfẹ, ki ẹnyin ki o lè mâ ni anito ohun gbogbo nigbagbogbo, ki ẹnyin ki o sì lè mâ pọ̀si i ni gbogbo iṣẹ rere, gẹgẹ bi a ti kọ o sinu iwe pe: O ti fún kalẹ, o ti fifun awọn talakà; ododo rẹ̀ duro lailai. Ọlọrun ti o fun afúnrugbìn li irugbìn, yio sì fun nyin li onjẹ lati jẹ, yio sì sọ irugbìn nyin ti ẹ ti fún di pupọ̀, yio sì mu ki eso ododo nyin ki o pọ̀si i.

Graduali. Oluwa, iwọ ti dán ọkàn mi wò,

iwọ sì bẹ ẹ wò li oru ; iwọ ti fi inú dán mi wò, iwọ kò sì ri iṣẹ buburu ninu mi, Alleluia, alleluia. Lọrensu lefiti mimọ ti ṣe iṣẹ rere kan, nigbati o fun awọn afọju li iriran nipa àmi agbelebu. Alleluia.

Ihin rere (Joh. xii, 24).

Nighanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : Lôtọ, lôtọ ni mo wí fun nyin, bikoṣe pe wóro alikama ba họ silẹ, ti o ba sì kú, o wà on nikan, ṣugbọn bi o ba kú, o so eso pupọ jade. Ẹniti o ba fẹ ẹmí rẹ, yio sọ ọ nù ; ẹniti o ba sì korira ẹmí rẹ li aiye yi, yio pa a mọ titi fi di iye ainipẹkun. Ẹnikẹni ti o ba fẹ sìn mi, ki o mâ tọ mi lẹhin ; nibiti emi ba sì wà, nibẹ ni iranṣẹ mi yio mâ wà pẹlu. Bi ẹnikẹni ba nsìn mi, on ni Baba mi yio bọlá fun.

Ifitọrẹ. Iyìn ati ẹwa li o wà niwaju rẹ ; iwa mimọ ati ọlá nla mbẹ ninu ibí mimọ rẹ.

Adura ti a hà jeje.

Oluwa, fi ojurere gbà ẹbọ ti a nrú si O, ki o sì jẹ ki o lè jẹ anfani fun igbalà wa nipa itoye ati ijiyà Lọrensu mimọ, ẹniti o kú nitori igbagbọ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹnikẹni ti o ba fẹ sìn mi, ki o mâ tọ mi lẹhin ; ibiti mo ba sì wà nibẹ ni iranṣẹ mi yio mâ wà pẹlu.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa ti a ti kún fun ẹbun mimọ rẹ,

ufi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbẹ Lorensu mimọ, ẹniti o kú nitori igbagbọ rẹ, ki o lè mu ise igbalà pọsi i ninu wa; nipase Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ MATTIU MIMỌ, APOSTOLI ATI EFANGELISTI

Li ọjọ 21n li osù Septemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹnu ọlọdodo ni imà sòrọ ọgbọ́n, ahọn rẹ a sì mà sòrọ ododo. Ofin Olọrun rẹ̀ mbẹ li ọkàn rẹ̀. *Ps.* Máṣe ṣe ifarawé awọn oluṣe buburu, ki iwọ kio má sì ṣe ilara si awọn ti nṣe iṣẹ ẹṣẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, fifunni, ki a lè ràn wa lọwọ́ nipa adura Mattiu mimọ́ Apostoli ati Efangelisti, ki a sì lè fi ohun wọnni fun wa nipa ẹbẹ rẹ̀, ti awa kò lè ri gbà nipa agbara awatikalawa; nipase Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Esek. 1, 10).

O ri gẹgẹ bi ti Marku mimọ́.

Graduali. Alabukún fun li ẹniti o bèru Oluwa, ti inu rẹ̀ dùn jọjọ lati pa ofin Rẹ̀ mọ́. Irú-ọmọ rẹ̀ yio lagbara li aiye; iran awọn olododo li a o bukún fun. Alleluia, alleluia. Ẹgbẹ awọn Apostoli ti o logo nyìn ọ, Oluwa, alleluia.

Ihin rere (Mat. IX, 9).

Nigbanâ ni Jesu ri ọkọnri kan ti a npè ni ni Mattiu, ti o joko ni bode ; o sì wí fun u pe : Mâ tọ mi lẹhin. On sì dide lojukannâ, o sì tọ ọ lẹhin. O sì ṣe, bi Jesu ti joko tì onjẹ ni ile ọkọnri nâ, kiyesi i, ọpọ awọn agbowode ati ẹlẹṣẹ wá ibẹ, nwọn sì ba Jesu ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ joko tì onjẹ. Nigbati awọn Farisi ri i, nwọn wí fun ọmọ-ẹhin rẹ pe : Ẹṣe ti oluwa nyin fi mba awọn aghowode ati awọn ẹlẹṣẹ jẹun. Ṣugbọn nigbati Jesu gbọ, o wipe : Awọn ti ara wọn le, kò fẹ irànlọwọ onisegùn, bikoṣe awọn ti ara wọn kò dá. Nitorinâ ẹ lọ, ki ẹ sì kọ bi a ti mọ eyi si : Emi nfẹ ânu jù ẹbọ lọ. Nitori emi kò wá ipè awọn olododo, bikoṣe awọn ẹlẹṣẹ si irònupiwada.

Ifitọrẹ Iwọ fi adé okuta iyebiye dé e lori : O tọrọ ẹmí lọwọ Rẹ, Iwọ sì fifun u. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ

Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ẹbọ ijọ enia rẹ ki o lè jẹ atẹwọgbà fun ọ nipa ẹbẹ Mattiu mimọ Apostoli ati Efangelisti, nipa iwàsu rere ẹniti a ti kọ ọ li ẹkọ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa. Amin.

Komunioni. Ogo rẹ pọ nipa igbalà ti Iwọ ti fifun u : Ogo ati ẹwa nla ni iwọ sì kún u fun, Oluwa.

Adura lẹhin komunioni.

Lẹhin igbati awa ti gbà sakramenti mimọ

rẹ, Oluwa, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, nipa ẹbẹ Mattiu mimọ, Apostoli ati Efangelisti jẹ ki ohun ijinlẹ mimọ ti a ti ṣe li ọlá rẹ ki o lè jẹ anfani fun igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ MIKAELI MIMỌ, OLORI ANGẸLI

Li ọjọ 29ⁿ ti oṣù Septemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹ fi ibukún fun Oluwa, ẹnyin Angẹli Rẹ gbogbo, ti o lagbara pupọ, ti nṣe ifẹ Rẹ, ti o sì ngbọ ohùn aṣẹ rẹ. *Ps.* Fi ibukún fun Oluwa mi, iwọ ọkàn mi, ati gbogbo ohun ti o wà ninu mi, ẹ fi ibukún fun orukọ Rẹ mimọ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o ti làna iṣẹ isìn awọn Angẹli ati ti enia li ọna iyanu, nipa ànu rẹ tifunni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki awọn ẹniti nduro niwaju rẹ lati mâ sìn Ọ nigbagbogbo li ọrun ki o lè mâ dâbobo wa lori ilẹ aiye; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Epistoli (Ifihàn I, 1).

Li ọjọ wọnyi li Ọlọrun fi ohun ti yio ṣẹ li ọjọ ti kò pẹ hàn, nipa fifi i ranṣẹ lati ọwọ Angẹli rẹ wá si Johanu iranṣẹ rẹ, ẹniti o jẹri ọrọ Ọlọrun, ti o sì jẹri ohun gbogbo ti o ri niti Jesu-Kristi. Alabukún fun li ẹniti nkà, ti o sì

ngbó òrọ isọtẹlẹ yi, ti o sì npa nkan wọnyi ti a ti kọ sinu rẹ mọ; nitori ìgba kù si dẹdẹ. Johanu si ajọ meje ti awọn onigbagbọ ti mbẹ ni Asia : Ore-ọfẹ wà fun nyin ati alafia lati ọdọ rẹ wá ẹniti mbẹ, ti o ti wà, ti o sì mbọ̀ wá, ati lati ọdọ awọn Ẹmí meje ni wá ti mbẹ niwaju itẹ́ rẹ, ati lati ọdọ Jesu-Kristi wá, ẹniti iṣe ẹlẹri olõtọ, ẹni-akọbi ninu awọn okú, ati alade awọn ọba aiye, ẹniti o fẹ wa, ti o sì wẹ̀ wa ninu ẹ̀jẹ rẹ kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa.

Graduali. Ẹ fi ibukún fun Oluwa, gbogbo ẹnyin Angẹli rẹ, ti o lagbara pupọ̀, ti o sì nṣe ifẹ́ rẹ. Fi ibukún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi ; ati ohun gbogbo ti o wà ninu mi, ẹ ti ibukún fun orukọ rẹ mimọ́. Alleluia, alleluia. Mikaeli mimọ́, olori Angẹli, dãbobo wa ninu ija, ki awa ki o máṣe ṣegbé li ọjọ́ idajọ ti o lẹ̀ru. Alleluia.

Ihin rere (Mat. XVIII, 1).

Nigbanà ni awọn ọmọ-ẹhin tọ̀ Jesu wá, nwọn sì wí fun u pe : Tali ẹniti iwọ nrò pe o tobi jù ni ijọba ọrun ? Jesu sì pè ọmọ kekere kan sọdọ rẹ, o mu u duro lãrin wọn, o sì wí fun wọn pe : Lõtọ ni mo wí fun nyin, bikoṣe pe ẹnyin ba yipada, ki ẹ sì dabi awọn ọmọ kekere. ẹnyin kì yio lè wọ̀ inu ijọba ọrun. Nitorinà ẹniti o ba rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ bi ọmọ kekere yi. on nã ni yio tobi jù ni ijọba ọrun. Ẹnikẹni ti o ba sì gbà irú ọmọ kekere yi kan li orukọ mi, o gbà mi. Sugbọn ẹnikẹni ti o ba fi apẹrẹ buburu mu ọkan ninu awọn kekere wọnyi ti

o gbà mi gbọ́ dẹ̀ṣẹ, iba san fun u ki a so ọlọ mọ́ ọ li ọrùn, ki a sì rì i si ibú okun. Egbé ni fun aiye nitori awọn skandali (tabi apẹrẹ buburu imunidẹ̀ṣẹ)! Nitori awọn apẹrẹ buburu imunidẹ̀ṣẹ kò lè ṣaide, ṣugbọn egbé ni fun oluwa rẹ̀ nâ nipasẹ ẹniti apẹrẹ buburu imunidẹ̀ṣẹ nâ ti wá. Njẹ nitorinà bi ọwọ́ rẹ tabi ẹsẹ rẹ ba mu ọ dẹ̀ṣẹ, ke wọn kuro, ki o sì jù wọn jina si ọ; o san fun ọ, ki o ṣe akewọ́, tabi akesẹ wọ̀ inu iye lọ, jù ki o li ọwọ́ meji tabi ẹsẹ meji, ki a sì gbé ọ jù sinu iná ti kò nipẹkun lọ. Bi oju rẹ ba mu ọ dẹ̀ṣẹ, yọ ọ jade ki o sì jù u jina si ọ; o san fun ọ ki o wọ̀ inu iye lọ li olojukan, jù ki o li oju meji, ki a sì gbé ọ jù sinu iná ọrun-apâdi lọ. Ẹ kiyesara, ki ẹ máṣe gàn ọkan ninu awọn ọmọ kekere wọnyi; nitori mo wí fun nyin, awọn Angẹli wọn li ọrun nwò oju Baba mi ti mbẹ li ọrun nigbagbogbo.

Ifilọrẹ. Angẹli kan duro niwaju altari ti on ti turibili tabi awo turari wura kan li ọwọ́; a sì fi turari pupọ̀ fun u: ẹ̀fí turari nâ sì goke lọ siwaju Ọlọrun. Alleluia.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa nrú ẹbọ iyìn si ọ, ni fifi irẹlẹ ọkàn bẹ̀bẹ̀ lodọ rẹ, ki o lè wù ọ lati fi ojurere gbà a nipa ẹ̀bẹ awọn Angẹli, ki o sì jẹ ki o lè ṣe anfani fun igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Gbogbo ẹnyin Angẹli Oluwa, ẹ fi ibukún fun Oluwa: Ẹ kọ orin iyìn si i, ki ẹ sì mâ yìn i logo lai ati lailai. Alleluia.

Adura lẹhin komunioni.

Nipa ẹbẹ Mikaeli mimọ́, olori Angẹli, ti a fi ti wa lẹhin, awa nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, jẹ ki awa ki o lè pa ohun nâ mọ́ li ọkàn mimọ́, ti awa ti fi ẹnu gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ AWỌN ANGẸLI OLUTỌJU

Li ọjọ́ 2i ti oṣù Oktoberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. O ri gẹgẹ bi ti Mikaeli mimọ́ (384).

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ẹniti ninu ipèse rẹ alailèsọ jade fiyesi i lati rán awọn Angẹli rẹ jade ki nwọn ki o mâ dâbobo wa, fifun awa ti mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki a lè mâ dâbobo wa nigbagbogbo nipa âbo wọn, ki a sì lè mâ yọ̀ ninu ẹgbẹ́ wọn titi aiye ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Eksodu xxiii, 10).

Nkan wọnyi li Oluwa Ọlọrun wí, kiyesi i, emi o rán Angẹli mi, ti yio ṣaju rẹ, ti yio sì dâbobo ọ li ọ̀na, ti yio sì mu ọ de ibi ti mo ti pèse silẹ. Bọ̀wọ fun u, ki o fetisi ohùn rẹ̀, kiyesara, ki o máṣe gàn a ; nitoriti kò darijì ọ nigbati iwọ ba dẹṣẹ, orukọ mi sì mbẹ lara rẹ̀.

Ṣugbọn bi iwọ ba fetisi ohùn rẹ, ti iwọ ba sì ṣe gbogbo eyiti mo paṣẹ fun ọ, emi o jasi ọtá awọn ẹniti nṣe ọtá rẹ, emi ọ sì pọ́n awọn nà loju ti npọ́n ọ loju, Angẹli mi yio sì ṣaju rẹ.

Graduali. Olọrun fi aṣẹ fun awọn Angẹli rẹ lati dàbobo ọ li ọ̀na rẹ gbogbo, li ọwọ́ won ni nwọn o sì gbé ọ soke, ki iwọ ki o má ba ti ẹsẹ rẹ ṣán okuta. Alleluia, alleluia. Ẹ fi ibukún fun Oluwa, gbogbo ẹnyin ọmọ-ogun rẹ̀, ẹnyin iranṣẹ rẹ̀ ti nṣe ifẹ rẹ̀. Alleluia.

Ihin rere.

O ri gẹgẹ bi ti Mikaeli mimọ́.

Ifitọrẹ. Ẹ fi ibukún fun Oluwa, gbogbo ẹnyin Angẹli rẹ̀, ẹnyin iranṣẹ rẹ̀ ti nṣe gẹgẹbi ọrọ rẹ̀, ti o sì nfetisi ohùn aṣẹ rẹ̀.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Olọrun, gbà ẹbọ ti a nrú si ọ li ọlá awọn Angẹli rẹ mimọ́, ki o sì fi ànu fifun wa, pe nipa àbo won titilọ ki a lè mà bọ lọwọ́ ewu aiye yi, ki a sì lè de ibi iye ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. O ri gẹgẹ bi ti Mikaeli mimọ́.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, awa ti ri ohun ijinlẹ mimọ́ rẹ gbà ti awa ti ayọ̀ nitori ọdún mimọ́ ti awọn Angẹli rẹ mimọ́, awa sì mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, fifun wa, pe

nipa âbo wọn ki a lè bọ kuro ninu arekereke èṣu, ki a sì lè mâ pa wa mọ kuro ninu gbogbo ohun ipanilara; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

ỌJỌ TI LUKU MIMỌ, AKỌWE IHIN RERE

Li ọjọ́ 18n ti oṣù Oktoberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Olorun, awọn ọrẹ rẹ li a sọ di ọlọlá jojo fun mi, a sì fi ẹsẹ itẹ́ wọn mulẹ gidigidi. *Ps.* Oluwa, iwọ ti dán mi wò, iwọ sì ti mọ mi : iwọ mọ ijoko ati idide mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Olorun, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, jẹ ki Luku mimọ, Akọwe Ihin rere rẹ, ki o lè mâ bẹbẹ fun wa lodọ rẹ; eniti o gbé ijiyà agbelebu si ara rẹ nigbagbogbo nitori ọlá oruko rẹ mimọ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (2 Kor. VIII, 16).

Ẹnyin ará mi, mo dupẹ fun Olorun nitoriti o fi aniyàn kannâ yi si ọkàn Titu fun nyin; nitori kò gbà kìki ẹbẹ mi nikan, sugbọn bi o ti kún fun itara pupọ, o lọ pẹlu ifẹ inu rẹ sodọ nyin. Awa ti rán arakọnrin wa nâ pẹlu rẹ, eniti o di olokiki ninu gbogbo ajọ awọn onigbagbọ nipa Ihin rere ti o wâsu; ki sì ṣe kìki

eyini nikan, ṣugbọn ẹniti a ti yàn pẹlu lati ọdọ awọn ajọ awọn onigbagbọ wá bi alabarìn wa, ati lati ṣe itọju awọn ọrẹ-ânu nâ, ti a nṣe ipinfuni wọn nipasẹ wa fun ogo Oluwa, ati gẹgẹ bi awa ti rò pe o dara. Iro wa ni ṣiṣe bẹ ni lati yẹra kuro ninu eyi, ki ẹnikẹni ki o máṣe sòrọ wa ni buburu lẹhin nitori ọpọlọpọ ọrẹ-ânu yi ti a ṣe ipinfuni wọn nipasẹ wa; Nitori awa ngbiyanju lati ṣe rere, kì iṣe kìki niwaju Olọrun nikan, ṣugbọn niwaju enia pẹlu. Awa sì ti rán ọkan ninu awọn arakọnrì wa pẹlu wọn, ẹniti awa ti ri nigbakugba ni ṣiṣe onitara fun iṣẹ rere, ti o sì jẹ onitara gbigbona jù bẹ lọ nisisiyi nitori igbẹkẹle nla ti o ni si nyin. Nitorinâ ibaṣe nitori Titu, ẹniti iṣe ẹgbẹ ati olubaṣiṣẹ mi lodọ nyin, tabi nitori awọn arakọnrì wa, ti iṣe iranṣẹ awọn ajọ awọn onigbagbọ ati ogo Kristi, ẹ fi àmi ifẹ nyin hàn wọn niwaju gbogbo ajọ awọn onigbagbọ nipa ọpọ ọrẹ-ânu, ati li ọna bayi ẹ fi hàn pe awa ti fi jare lati ṣogo nitori nyin.

Graduali Iró wọn kànka gbogbo aiye, ọrọ wọn sì de opin aiye. Awọn ọrun nrohìn ogo Olọrun, ati ofurufu nfi iṣẹ ọwọ rẹ hàn. Alleluia, alleluia. Emi li o yàn nyin, ki ẹnyin ki o lè lọ, ki ẹ sì so eso, ki eso nyin ki o lè duro. Alleluia.

Ihin rere.

O ri gẹgẹ bi ti Marku mimọ.

Ifitọrẹ. Olọrun, awọn ọrẹ rẹ li a sọ di ọlọlá jojọ, a sì fi ẹsẹ itẹ wọn mulẹ gidigidi.

Adura ti a kà jẹ́ẹ́.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, fun wa nipa agbara ẹ̀bun rẹ ọrun fi òre-ọfẹ lati mà fi ifàiyabalẹ sìn Ọ, ki o sì jẹ nipa ẹ̀bẹ Luku mimọ́, akọwe Ihin rere rẹ, ki ẹ̀bọ ti awa nrú si ọ ki o lè fi ogo ti kò nipẹkun fun wa; nipasẹ Jesu-Kristi, Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹnyin ti o ntọ̀ mi lẹhin yio joko lori itẹ́, enyin o si mà ṣe idajọ awọn ẹ̀ya Israeli mejejila.

Adura lẹhin komunioni.

Olọrun Olodumare awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, fifunni, ki eyiti awa ti gbà lati ori altari mimọ́ rẹ wá, ki o lè sọ okàn wa di mimọ́ nipa ẹ̀bẹ Luku mimọ́, akọwe Ihin rere rẹ, ki o si lè mà pa wa mọ́ fi alafia; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN AWỌN APOSTOLI MIMỌ

Ipilẹsẹ ti Misa. Olọrun, awọn ọrẹ́ rẹ li a sọ di ọlọlá jọjọ fun mi, a sì fi ẹsẹ itẹ́ wọn mulẹ gidigidi. *Ps.* Oluwa, iwọ ti dán mi wò, iwọ sì ti mọ̀ mi : iwọ mọ̀ ijoko ati idide mi. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Olọrun, Iwọ ẹniti o ti wù ki awa ki o lè wá

sinu imọ̀ orukọ rẹ mimọ́ nipasẹ awọn Apostoli rẹ mimọ́, tifunni, ki awa ki o lè fi anfani bọlá fun ogo wọn ti kò nipẹkun, ati nipa ṣiṣe bẹ̀ ki a lè mâ lọ siwaju ninu gbogbo iṣẹ rere ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Efes. iv, 7).

Ẹnyin ará mi olukuluku wa li a fi ôre-ọfẹ fun gẹgẹ bi oṣuwọn ẹbun Kristi. Nitorinâ Iwe mimọ́ wipe : Nigbati O goke lọ si ọrun, o mu ọ̀pọlọpọ igbekun ni igbekun lọ, o sì ti fi ẹbun rẹ̀ fun awọn enia. Ṣugbọn ẹṣẹ ti a fi wí pe O goke lọ si ọrun, bikoṣe pe on ti sọkalẹ ni isiwaju lọ si ìha isalẹ aiye? Ẹnikan nâ ti o ti sọkalẹ li o sì ti goke lọ si ibiti o ga jù gbogbo ọrun lọ, ki o lè kún ohun gbogbo. On li o sì ti sọ awọn ẹlomiran di Apostoli, awọn ẹlomiran di woli, awọn ẹlomiran di akọwe Ihin rere, ati awọn ẹlomiran di oluṣọ-agutan ati olukọni lati ṣe awọn enia mimọ́ li aṣepé, fun iṣẹ isìn Ọlọrun, fun idàgbasoke ara Kristi (tabi ijọ awọn kristiani), titi gbogbo wa yio fi wá sinu iṣọkan ti igbagbọ́, ati sinu imọ̀ Omọ Ọlọrun, si iwa ọkọnri pipé kan, si oṣuwọn ọ̀dún kikún ti Jesu-Kristi.

Graduali. Iwọ o mâ fi wọn jẹ ọmọ-alade lori ilẹ gbogbo, nwọn o mâ ranti orukọ rẹ, Oluwa. Lipò awọn baba nla rẹ li a ti bi awọn ọmọkọnri fun ọ. Nitorinâ ni awọn enia yio ṣe má yìn ọ lai ati laila. Alleluia, alleluia. Ọlọrun, nwọn ọrẹ rẹ li a sọ di ọlọlá jọjọ, a sì fi ẹsẹ itẹ́ wọn mulẹ gidigidi. Alleluia.

Ihin rere.

O ri gẹgẹ bi ti Iyipada Apostoli Paulu mimọ.

Ifitọrẹ. Iró wọn kàn ka gbogbo aiye, ọrọ wọn sì de opin aiye.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, nipa bibọlá fun ogo ainipẹkun ti awọn Apostoli mimọ rẹ, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifunni, ki a lè bọ kuro ninu ẹṣẹ wa nipa ohun ijinlẹ mimọ yi, ki a ba lè bọlá fun wọn bi o ti yẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Komunioni. Ẹnyin ti o ntọ mi lẹhin yio oko lori itẹ, ẹnyin o sì mâ ṣe idajọ ẹya Israeli mejejila.

Adura lẹhin komunioni.

Lẹhin gbigbà sakramenti mimọ rẹ, awa nfi irẹlẹ okàn bẹbẹ lọdọ rẹ, Oluwa, fifunni, pe nipa ẹbẹ awọn Apostoli rẹ mimọ. ki ohun ti a mbọlá fun li iranti ikú wọn nitori igbagbọ rẹ ki o lè jẹ anfani fun igbalà wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN ENIA MIMỌ KAN TI IṢE MARTIRI ATI BIṢOPU.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹnyin saserdoti Oluwa, ẹ fi ibukún fun Oluwa! ẹnyin enia mimọ ati oni-

rẹlẹ ọkàn, ẹ yìn Ọlọrun *Ps.* Gbogbo ẹnyin iṣẹ Oluwa, ẹ ti ibukún fun Oluwa, ki ẹ sì mà yìn I logo lai ati lailai. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ẹniti o mu wa yọ lọdọdún nipa ọdún mimọ́ ti N...., Martiri ati Bíṣopu rẹ mimọ́, tifunni, ki ẹniti a nṣe ọdún mimọ́ rẹ̀ li aiye ki o lè jẹ alàbo wa li ọrun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (2 Kor. 1).

Ibukún ni fun Ọlọrun, ati Baba Oluwa wa Jesu-Kristi, Baba ànu, ati Ọlọrun ti gbogbo itunu, ẹniti ntù wa ninu ni gbogbo wahalà wa, ki awa pẹlu ki o lè mà tù awọn ti o wà ninu onirúru wahalà ninu, nipa itunu kannà ti a fi ntù awa tikalawa ninu lọdọ Ọlọrun wá. Nitoripe bi ijiyà Kristi ti di pipọ̀ ninu wa, bẹ̀ gẹgẹ ni itunu wa dì pipọ̀ nipa Kristi pẹlu. Bi a ba pọ́n wa loju, nitori igbiyanju ati igbalà nyin ni; bi a ba ntù wa ninu, nitori itunu nyin ni; bi a ba ngbà wa niyanju, nitori igbiyanju ati igbalà nyin ni, eyiti o ṣiṣẹ ifãiya ran iya kannà ti awa njẹ pẹlu: ki ireti wa nipa ti nyin ki o lè duro ṣinṣin, awa mọ̀ pe, bi ẹnyin ti jẹ alabapin ninu ijiyà, bẹ̀ni ẹnyin o si jẹ alabapin pẹlu ninu itunu wa, ninu Kristi Jesu Oluwa wa.

Graduali. Iwọ ti fi ogo ati ọlá dé e ladé; Iwọ mu u joba lori iṣẹ ọwọ́ rẹ, Oluwa. Alleluia, alleluia. Eyi ni saserdoti ti Oluwa dé ladé. Alleluia.

Ihin rere (Mat. xvi, 24).

Nigbanà ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : Bi ẹnikan ba nfẹ lati tọ mi lẹhin, ki o sẹ ara rẹ, ki o gbé agbelebu rẹ, ki o si mà tọ mi lẹhin. Nitori ẹnikẹni ti o ba fẹ gbà ẹmi rẹ là, yio sọ ọ nù ; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba sọ ẹmi rẹ nù nitori mi, yio ri i gbà. Nitori anfani kini fun enia, bi o ba jère gbogbo aiye, ti o si sọ ẹmi rẹ nù ? Tabi kini enia yio lè fi ṣe paṣipàrọ ọkàn rẹ ? Nitori Ọmọ-enia yio wá ninu ogo Baba rẹ pẹlu awọn Angẹli rẹ, nigbanà ni yio fi ère olukuluku fun u gegẹ bi iṣẹ rẹ.

Ifitọrẹ. Mo ti ri Dafidi, iranṣẹ mi ; ororo mimọ mi ni mo ta si i lori. Nitori ọwọ mi yio ràn a lọwọ, apa mi yio mà mu u lagbara.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, sọ ọrẹ-ẹbọ yi ti a ti yà si mimọ fun ọ di mimọ, ati nipa ẹbẹ N... , martiri ati bisopu rẹ mimọ fi ojurere wò wa nipasẹ ohun kannà.

Komunioni. Oluwa, iwọ ti fi adé okuta iyebiye dé e lori.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki komunioni yi ki o lè wẹ wa nù kuro ninu ẹṣẹ wa, ati nipa ẹbẹ N ..., martiri ati bisopu rẹ mimọ, sọ wa di alabapin ninu ohun imunilarada ti ọrun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN ENIA MIMỌ KAN TI IṢE MARTIRI, LAIṢE BIṢOPU.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, olododo yio mâ yọ li agbara rẹ, yio si mâ yọ gidigidi nitori igbalà ti iwọ ti fifun u; iwọ ti ṣe ifẹ ọkàn rẹ fun u. *Ps.* Iwọ ti fi ibukún ôre kò o li ọ̀na, iwọ si fi adé okuta iyebiye dé e lori. Ogo ni fun Baba, etc,

Adura

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, fifunni, pe bi awa ti nṣe ọdún mimọ́ ti ọjọ́ ibí si aikú ti N.... mimọ́, bẹ gẹgẹ ni nipa ẹbẹ rẹ ki a lè mâ fi ẹsẹ wa mulẹ gidigidi ninu ifẹ orukọ rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Iwe ọgbọ́n x, 10).

Oluwa ti ṣamọ̀na olododo là ọ̀na otitọ já, o si fi ijọba Ọlọrun hàn a, o si fi ẹkọ́ awọn enia mimọ́ fun u. O so ọ di ọlọlá ninu iṣẹ rẹ, o si ṣe iṣẹ rẹ pari. O dàbobo o kuro lọwọ́ awọn ọtá rẹ, o si pa a mọ́ kuro lọwọ́ awọn ẹlẹtàn; o si fi ijà lile kan fun u, ki o lè jẹ aṣẹgun, ki o si mọ́ pe ọgbọ́n lagbara jù ohun gbogbo lọ. On kò fi olododo silẹ nigbati a ti tà a, ṣugbọn o ti gbà a kuro lọwọ́ ẹlẹṣẹ: O ba a sọkalẹ lọ sinu tubu, kò si fi i silẹ ninu èwọn, titi o fi fi ọpa ọba le e lọwọ́, ti o si fun li agbara lori awọn ti nní i lara; O si fi awọn nâ hàn bi eleké, ti o fi ẹsùn sùn u; Oluwa Ọlọrun wa si fi ogo ainipẹkun fun u.

Graduali. Alabukún fun li ẹniti o bèru Oluwa, ti inu rẹ̀ sì dùn jọjọ lati pa ofin rẹ̀ mọ́. Irú-ọmọ rẹ̀ yio lagbara li aiye : iran awọn olododo li a o bukún fun. Alleluia, alleluia. Oluwa iwọ ti fi adé okuta iyebiye dé e lori. Alleluia.

Ihin rere (Mat. x, 34).

Nigbanà ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ẹ máṣe rò pe emi ti wá lati mu alafia wá si aiye, emi kò wá lati mu alafia wá, bikoṣe idà. Nitori emi ti wá lati yà ọmọkọnri kuro lọdọ baba rẹ̀, ati ọmọbirin kuro lọdọ iyá rẹ̀, ati ayamọ kuro lọdọ iyákọ rẹ̀ ; awọn ọtá enia li awọn ará ile rẹ̀ yio si mà ṣe. Ẹnikẹni ti o ba fẹ baba tabi iyá rẹ̀ jù mi lọ, kò yẹ fun mi : Ẹniti o fẹ ọmọkọnri tabi ọmọbirin jù mi lọ, kò si yẹ fun mi. Ẹniti kò ba si gbé agbelebu rẹ̀, ki o si má tọ̀ mi lẹhin, kò yẹ fun mi. Ẹniti o ba pa emí rẹ̀ mọ́, yio sọ ọ nù, ẹniti o ba sọ emí rẹ̀ nù nitori mi, yio ri i gbà. Ẹniti o ba gbà nyin, o gbà mi, ẹniti o ba si gbà mi, o gbà ẹniti o ràn mi. Ẹniti o ba gbà woli li oruko woli, yio ri ère woli gbà ; ẹniti o ba gbà olododo li oruko olododo, yio ri ère olododo gbà. Ẹnikẹni ti o ba fi ago omi tutù fun ọkan ninu awọn ẹni-ikẹhin wọnyi lati mu li oruko ọkan ninu awọn ọmọ-ẹhin mi, lôtọ ni mo wí fun nyin kì yio padanù ère rẹ̀.

Ifitọrẹ. Ogo ati ọlá li iwọ ti fi dé e ladé ; iwọ si ti mu u joba lori iṣẹ ọwọ́ rẹ, Oluwa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, gbà ọrẹ-ẹbọ ati adura wa, ki o wẹ̀ wa nù nipa ohun ijinlẹ rẹ ti ọrun, ki o sì fi ânu rẹ gbọ́ ti wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ẹnikẹni ti o ba nfẹ́ tọ̀ mi lẹhin, ki o sẹ́ ara rẹ̀, ki o gbé agbelebu rẹ̀, ki o sì mâ tọ̀ mi lẹhin,

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Ọlọrun wa, awa mbẹ̀bẹ̀ lọdọ rẹ, fifunni, pe nipa ṣiṣe iranti awọn enia mimọ́ rẹ bi awa ti yọ̀ ninu ọdún mimọ́ kan ti o lopin, bẹ̀ gẹgẹ ni ki a lè mâ yọ̀ ninu ojukoju wọn li aiye ti kò nipẹkun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN ỌPỌLỌPỌ ENIA MIMỌ TI IṢE MARTIRI.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Lati ọwọ́ Oluwa wá ni igbalà awọn olododo, on li âbo wọn ni ìgba ipọnju. *Ps.* Kiyesara, ki iwọ ki o máṣe ṣe ifarawé awọn oluṣe buburu; bẹ̀ni ki iwọ ki o má sì ṣe ilara si awọn ti nṣiṣẹ̀ ẹṣẹ. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa, Iwọ ẹniti o mu inu wa dùn lọdọdún nipa ọdún mimọ́ ti awọn martiri mimọ́ rẹ N.. N.. , lojurere ânu rẹ fifunni, ki awa máṣe fi kiki inu-didùn ṣe iranti itoye wọn nikan, ṣug-

bọn ki a lè mâ gbà wa niyanju si gbogbo iṣẹ rere nipa apẹrẹ rere wọn pẹlu; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Heb. x, 32).

Ẹnyin ará mi, ẹ ṣe iranti ọjọ́ iṣaju, ninu eyiti, lẹhin igbati a ti tàn imọlẹ si nyin nipa ibatisi, ẹnyin fi ara gbà ijà nla ti ipọnju, lapakan nigbati a sọ nyin di ẹni-ifiṣẹlẹya nipa ẹgàn ati ipọnju, ati lapakeji, nigbati ẹnyin di ẹgbẹ awọn ti nwọn lò bẹ. Nitoriti ẹnyin ṣãnu fun awọn ti o wà ninu ẹwọn, ẹnyin si fi ayọ̀ gbà ijalole ti ẹrù nyin, nipa mimọ̀ pe ẹnyin ni ọrọ̀ ti o dara jù bẹ lọ, ti yio si duropẹ titi. Nitorinâ ẹ máṣe sọ igbẹkẹle nyin nù, ti o ni ère nla. Nitoripe ẹnyin kò lè ṣe alaini sùru, pe nipa ṣiṣe ifẹ Ọlọrun ki ẹnyin ki o lè ri ohun ti a ti ṣe ileri fun nyin gbà. Nitori niwọn ìgba diẹ si i, ẹniti mbọ̀ yio de, ki yio si pẹ. Ṣugbọn olododo enia mi yio wà làye nipa igbagbọ́.

Graduali. Awọn olododo nkigbe si Oluwa, Oluwa sì gbọ́ ti wọn, o sì gbà wọn kuro ninu gbogbo wahalà wọn. Oluwa mbẹ leti ọdọ awọn ti iṣe onirònbanujẹ ọkàn, yio sì gbà awọn onirẹlẹ ọkàn là. Alleluia, alleluia. Ogun alaṣọ funfun ti awọn martiri nyìn ọ, Oluwa. Alleluia.

Lẹhin ijọ́ ọsẹ Septuagesima, lipò Alleluia, *etc , a wi eyiti o tẹle yi pe :*

Awọn ti nfi omije fún irugbìn, yio fi ayọ̀ kà. Nwọn nrìn lọ ti awọn ti isọkún, nwọn sì nfún irugbìn. Ṣugbọn nwọn yio fi ayọ̀ pada wá, nwọn yio sì rù itì wọn.

Ihin rere (Mat. XXIV, 3).

Nigbati Jesu joko lori òke Olifi, awọn ọmọ-ẹhin rẹ tọ ọ wá nikọ̀kọ, nwọn sì wipe : Sọ fun wa nigba wo ni nkan wọnyi yio ṣẹ? Kini yio sì ṣe àmi wiwá rẹ ati ti opin aiye? Jesu sì da wọn lohùn wipe. Ẹ mâ kiyesara, ki ẹnikẹni ki o máṣe tàn nyin jẹ. Nitori ọ̀pọ̀lọpọ enia yio wá li orukọ mi, ti nwọn yio sì wipe : Emi ni Kristi; nwọn yio sì tàn ọ̀pọ̀lọpọ enia jẹ. Ẹnyin o sì gburó ogun, ati idagiri ogun, ẹ kiyesara, ki a máṣe pa nyin lâiya. Nitori nkan wọnyi kò lè ṣaiṣẹ, ṣugbọn opin nâ kì iṣe isisiyi : Nitori orilẹ-ède yio dide si orilẹ-ède, ati ijọba si ijọba; ajakalẹ-arùn, ìyan ati iṣẹlẹ yio sì wà ni ibi pupọ̀. Ṣugbọn gbogbo nkan wọnyi ni ipilẹṣẹ ipọnju nikan, nigbanâ ni nwọn o fi nyin lé oró ati ikú lọwọ́; gbogbo orilẹ-ède yio sì korira nyin nitori orukọ mi. Nigbanâ ni ọ̀pọ̀lọpọ enia yio ṣubu sinu ẹ̀ṣẹ, nwọn o mâ fi ara wọn hàn, nwọn o sì korira ara wọn. Woli eké pupọ̀ ni yio sì dide, nwọn o sì tàn ọ̀pọ̀lọpọ enia jẹ. Nitoriti ẹ̀ṣẹ sì di pupọ̀, ifẹni ti ọ̀pọ̀lọpọ enia yio sì dì tutù. Ṣugbọn ẹniti o ba foritì i titi di opin, on nâ li a o gbà là.

Ifitọrẹ. Okàn awọn olododo mbẹ li owó Olọrun, oró ikú ainipẹkun kì yio fọwọkàn wọn. Loju awọn aṣiwère, nwọn dabi ẹnipe nwọn ti kú, ṣugbọn nwọn wà li alafia.

Adura ti a kà jeje

Oluwa, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, rẹ̀ ibinu rẹ silẹ

nipa ẹbọ ti a rú si ọ; ati nipa ẹbẹ awọn martiri rẹ mimọ N... N..., pẹ̀ wa mọ́ kuro ninu gbogbo ewu; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ohun ti mo ba wí fun nyin li òkunkun, ẹ ni ki ẹnyin ki o sọ ni imọlẹ; ati ohun ti ẹnyin ba gbọ́ si etí ni ki ẹ wàsu lori orule.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki komunioni yi ki o lè wẹ̀ wa nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ wa; ati nipa ẹbẹ awọn martiri rẹ mimọ N... N..., sọ wa di alabapin ninu ohun imunilarada ti ọrun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN ENIA MIMỌ KAN, TI IṢE ONIJẸWỌ ỌLỌRUN ATI BIṢOPU.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Oluwa, jẹ ki a fi ododo wọ̀ awọn saserdoti rẹ, ki o si jẹ ki awọn enia mimọ́ rẹ ki o mâ yọ̀ : nitori Dafidi, iranṣẹ rẹ, máṣe yi oju ẹni-ita ororo si rẹ pada. *Ps.* Oluwa, ranti Dafidi ati ìwa tutù rẹ̀ gbogbo. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, fifunni, ki ọdún mimọ́ ti onijẹwọ ati biṣopu rẹ mimọ́ N..., ti a nfi tọwọtọwọ ṣe, ki o lè mâ sún ifọkansìn ati igbalà wa siwaju; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Heb. VII, 23).

Ẹnyin ará mi, ọ̀pọ̀lọpọ̀ saserdoti ni nwọn iṣe ninu Majẹmu lailai, nitoriti nwọn kò lè wà titi nitori ikú. Ṣugbọn bi Jesu ti duro titilai, o ni oyè saserdoti ti kò nipẹkun. Nitorinâ nigbagbogbo ni on lè gbà awọn ti o sunmọ́ ọdọ Ọlọrun nipasẹ rẹ̀ lâ; nitoriti o wà lâye titilai lati mâ bẹ̀bẹ̀ fun wa. Nitoripe o yẹ jojọ́ ki awa ki o ni irú olori saserdoti bi eleyi, ti iṣe mimọ́, alailẹbi ẹ̀ṣẹ, alailabawọ́n, ti a ti yà sọtọ kuro ninu awọn ẹ̀lẹ̀ṣẹ, ti a sì gbé ga jù awọn ọrun lọ; ẹniti kò ni irubọ ti ṣe lojojumọ, gẹgẹ bi awọn saserdoti miran, ni akọṣe fun ẹ̀ṣẹ ara rẹ̀, ati lẹhinnâ fun ẹ̀ṣẹ awọn enia; nitoripe eyi ni Jesu-Kristi Oluwa wa ti ṣe lẹ̀kan, nigbati o fi ara rẹ̀ tikalarẹ̀ rubọ.

Graduali. Emi yio fi igbalà wọ̀ awọn saserdoti rẹ̀ laṣọ; awọn enia mimọ́ rẹ̀ yio sì mâ yọ̀ gidigidi. Nibẹ̀ li emi o gbé fi agbara Dafidi hàn; emi ti mura fitila kan silẹ̀ fun ẹni-ita ororo si mi. Alleluia, alleluia. Oluwa ti bura, on kì yio sì yi pada: Iwọ ni saserdoti titilai, nipa ẹsẹ Melkisedeki.

Ihin rere (Mat. XXIV, 42).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe: Ẹ mâ ṣọ́na, nitori ẹnyin kò mọ̀ wakati ti Oluwa nyin yio de. Nitori ẹ mọ̀ pe bi bâle ile ba mọ̀ akokò nâ ti olè yio wá, dajudaju on iba mâ ṣọ́na, on kì iba sì jẹ ki a run ile rẹ̀. Nitorinâ ki ẹnyin ki o mura silẹ̀ pẹlu, nitori Ọmọ-

enia yio wá li akokò nâ ti ẹnyin kò rò. Tani ẹnyin rò pe iṣe olôtọ ati ọlọgbọ́n ọmọ-ọdọ, ẹniti Oluwa rẹ̀ fi jẹ olori ará ile rẹ̀ lati fi onjẹ wọn fun wọn li akokò? Alabukún fun li ọmọ-ọdọ nâ, ẹniti oluwa rẹ̀, nigbati o ba de, yio bá ni ṣiṣe bẹ̀. Lôtọ́ ni mo wí fun nyin pe: On yio fi i jẹ olori gbogbo ohun iní rẹ̀.

Ifitọrẹ. Otitọ ati ânu mi yio wà pẹlu rẹ̀, ati li orukọ mi li a o gbé agbara rẹ̀ ga.

Adura ti a kà jeje.

Oluwa, awa nibẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki ọdún mimọ́ ti onijẹwọ ati bisopu rẹ mimọ́ N .., ti a nṣe lọdọdún, ki o lè so wa di atẹwọgbà fun ânu rẹ, pe nipa ẹbẹ rẹ̀ ki iṣẹ isin mimọ́ yi ki o lè fà ẹbun ôre-ọfẹ rẹ sori wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Alabukún fun li ọmọ-ọdọ nâ, ẹniti Oluwa rẹ̀, nigbati o ba de, yio bá ni ṣiṣe bẹ̀: Lôtọ ni mo wí fun nyin pe: On yio fi i jẹ olori gbogbo ohun iní rẹ̀.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun, Iwọ ti o fun olododo ọkàn li ère, fifunni, ki a lè ri idarijì ẹṣẹ wa gbà nipa ẹbẹ onijẹwọ ati bisopu rẹ mimọ́ N..., ọdún mimọ́ ẹniti a nṣe; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN ENIA MIMỌ KAN TI IṢE OLUKỌNI NINU EKLESIA.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ninu awujọ awọn onigbagbọ li Oluwa ti ṣí ẹnu rẹ, o sì kún fun ẹmí ọgbọ́n ati oyé, o sì ti fi aṣọ igunwà ogo wọ̀ ọ. *Ps.* Ohun rere ni lati mâ yìn Oluwa, ati lati mâ kọrin si ogo orukọ rẹ, Ọgá-ogo. Ogo ni fun Baba etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o fun awọn enia rẹ li Enia mimọ́ N... bi amọ̀na si igbalà ainipẹkun, fifunni, awa mbẹ̀bẹ lọdọ rẹ, ki ẹniti o ti kọ́ wa li ọ̀na iye li aiye yi, ki o lè mâ jẹ ẹlẹbẹ fun wa li ọrun; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (2 Timot. IV, 1).

Olufẹ mi, mo bẹ ọ niwaju Ọlọrun ati Jesu-Kristi, ẹniti yio da àye ati okú lẹjọ nìgba wiwá rẹ ati ijọba rẹ, ki o wâsu òrọ Ọlọrun, mâ fi aisimi rọ awọn enia li akokò ati laiṣe akokò, bá wọn wi, bẹ wọn, ki o sì fi ijiyà dẹrubà wọn ninu gbogbo sùru ati ẹkọ́; nitoripe ìgba yio de, ti awọn enia kì yio gbà ẹkọ́ ti o yè kóro mọ́, ṣugbọn nipa ifẹkufẹ ara wọn ni nwọn o kó òpọlọpọ olukọ́ jọ fun ara wọn, ti nwọn yio rìn wọn leti (tabi ti nwọn yio pọ́n wọn); nwọn o sì dití si otitọ, nwọn o sì yipada sinu ìtan asan. Ṣugbọn iwọ mâ ṣọ́ra nigbagbogbo, mâ foritì gbogbo lâla, mâ ṣe iṣẹ ti oniwâsu Ihin rere, mâ ṣe iṣẹ rẹ bi iranṣẹ; mâ jẹ alairekoja.

Nitoriti emi ti mura tán lati fi mi rubọ, akokò ikú mi sì sunmọ́ etile. Emi ti jà ijà rere, emi ti pari ìje mi, emi ti pa igbagbọ́ mọ́ : O kùn fun mi nikan lati reti adé ododo ti a fi lelẹ fun mi, ti Oluwa, onidajọ ododo, yio fi fun mi li ọjọ́ nla nà, kì sì ṣe fun emi nikan, ṣugbọn fun gbogbo awọn ti o fẹ́ wiwá rẹ̀ pẹlu.

Graduali. Ẹnu olododo ni imà sọ̀rọ ọgbọ́n, ahọ́n rẹ̀ a sì mà kọ́ni li ododo. Ofin Ọlọrun rẹ̀ mbẹ li ọkàn rẹ̀ ; ọkan ninu ìsisẹ rẹ̀ kì yio yẹ̀. Alleluia, alleluia. Oluwa ti fẹran rẹ̀, o sì ṣe e lọ́ṣọ ; o sì fi aṣọ igunwà ogo wọ̀ ọ. Alleluia.

Ihin-rere (Mat. v, 13).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ẹnyin ni iyọ̀ aiye : Nje bi iyọ̀ ba sọ adùn rẹ̀ nù, kini a o fi dùn u bi iyọ̀? Kò nilari fun nkan kan mọ́, bikoṣe pe ki a gbé e jù nù, ki enia sì má tẹ̀ ẹ mọlẹ. Ẹnyin ni imọlẹ aiye. Ilú ti o wà lori òke kò lè fi ara sin. A kì isi tàn fitila kan lati fi i sabẹ apoti oṣuwọn, bikoṣe lori ọpá fitila, ki o lè fi imọlẹ fun gbogbo awọn ti mbẹ ninu ile nà. Bẹ̀ gẹgẹ ni ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ niwaju awọn enia, ki nwọn ki o lè mâ yìn Baba nyin ti mbẹ li ọrun logo. E máṣe rò pe emi wá lati pa ofin tabi awọn woli run. emi kò wá lati pa wọn run, bikoṣe pe lati mu wọn ṣẹ. Nitoripe lôtọ ni mo wí fun nyin, ọrun on aiye kì yio koja lọ, ki ohunkohun ti o wà ninu ofin titidi iota kan tabi ohun kikini kan ki o to ṣẹ li aṣetan. Nitorinà ẹnikẹni ti o ba ru kikini kan ninu ofin wọnyi, ti o ba sì nkọ́ awọn enia

bę̀, on nâ li a o pè ni kikini li ijọba ọrun. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba nṣe wọn, ti o ba sì nkọ́ wọn, on nâ li a o mâ pè ni ẹni-nla li ijọba ọrun.

Ifitọrẹ. Olododo yio gbà bi igi ọpẹ, yio sì dàgba bi igi sedari ni Libanoni.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, jẹ ki awa máṣe rèhin ninu adura ifọkansìn ti Enia mimọ́ rẹ N..., ki o lè sọ ẹbọ wa di ateṣẹgbà fun ọ, ki o sì lè gbà idarijì ẹṣẹ wa lọdọ rẹ fun wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Eyi ni olôtọ ati ọlọgbọ́n ọmọ-ọdọ nâ, ẹniti Oluwa rẹ̀ ti jẹ olori ará ile rẹ̀, lati fi onjẹ wọn fun wọn li akokò.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, ki ẹbọ rẹ ki o lè fun wa ni igbalà, fifunni, ki onijẹwọ rẹ mimọ́ ati olukọ́ni rẹ ologo N .. ki o lè mâ jẹ ẹlẹbẹ fun wa lọdọ rẹ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN ENIA MIMỌ KAN TI IṢE ONIJẸWỌ ỌLỌRUN LAISE BIṢOPU.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ẹnu olododo ni imâ sọrọ ọgbọ́n, ahọ́n rẹ̀ a sì mâ kọ́ni li ododo : ofin

Ọlọrun rẹ mbẹ li ọkàn rẹ. *Ps.* Kiyesara, ki iwọ ki o máṣe ṣe ifarawé awọn oluṣe buburu, bẹ̀ni ki o má sì ṣe ilara si awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ. Ogo ni fun Baba etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ti o mu inu wa dùn lọdọdún nipa ọdún mimọ́ ti Onijẹwọ rẹ mimọ́ N. .., lojurere ânu rẹ fifunni, ki iranti ọjọ́ ibí rẹ si aikú ti a nṣe loni ki o lè gbà wa niyanju lati topasẹ ìwa rere rẹ; nipasẹ Jesu Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ekles. xxxi, 8).

Alabukún fun li ọkọnri nà ti a ri laini abukùn, ti kò sì lépa wura, bẹ̀ni ti kò sì gbẹkẹle owo tabi iṣura. Tani oluwa rẹ, ao sì yìn i? Nitoriti o ti ṣe ohun iyanu niwọn ọjọ́ aiye rẹ. A ti fi wura dán a wò, a sì ri i ni pipé, ogo rẹ kì yio sì nipẹkun. On ti lè dẹ̀ṣẹ, ṣugbọn kò dẹ̀ṣẹ, on ti lè ṣe ohun buburu, ṣugbọn kò ṣe wọn, nitorinà a ti fi idi ohun inú rẹ kalẹ ninu Oluwa, gbogbo ijọ awọn Enia mimọ́ ni yio sì mà rohìn ore-ânu rẹ ti o ti ṣe.

Graduali. Olododo yio gbà bi igi ọpẹ, yio sì dàgba ninu ile Oluwa gẹgẹ bi igi sedari ni Libanoni: lati fi ânu rẹ hàn li owurọ ati otitọ rẹ li oru. Alleluia, alleluia Alabukún fun li ọkọnri ti o fàiyaràn idánwò, nitori nigbati a ti ba dán a wò tán, yio gbà adé ìye.

Ihìn rere (Luk. xii, 35).

Nigbanâ ni Jesu wí fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ pe : Ẹ di amure, ki ẹ sì ni fìtila ti njó li ọwọ́ nyin, ki ẹnyin ki o sì dabi awọn ti nreti Oluwa wọn, nigbati on yio pada wá lati ibi iyawo, pe nigbati on ba de, ti o ba sì kànkun, ki nwọn ki o lè ṣí i silẹ fun u lọgan. Alabukún fun li irú awọn ọmọ-ọdọ bawọnyi ti Oluwa nâ, nigbati o ba de yio bá ni ṣíṣọna. Lõtọ ni mo wí fun nyin pe : on yio di ara rẹ li amure, yio sì mu wọn joko tì ounjẹ, yio sì sẹ agbawọ fun wọn nipa kikọja lati ọdọ ọkan si ekeji. Nigbati o ba sì de nigba iṣọ́ keji tabi iṣọ́ ẹkẹta, ti o sì bá wọn bẹ, alabukún fun ni awọn ọmọ-ọdọ wọnyi. Ṣugbọn ki ẹnyin ki o mọ̀ pe bi bâle nâ ba mọ̀ wakati ti olè yio wá dajudaju on iba ṣọna, on kì iba sì jẹ ki a run ile rẹ̀. Bẹ̀ gẹgẹ ni ki ẹnyin ki o mura pẹlu : nitori Ọmọ-enia yio wá li akokò nâ ti ẹnyin kò rò.

Ifitọrẹ. Otitọ ati ânu mi yio wà pẹlu rẹ̀, ati li orukọ mi li a o gbé agbara rẹ̀ ga.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa nrú ẹbọ iyìn si ọ li iranti awọn enia mimọ́ rẹ, nipa eyiti awa ngbẹkẹle lati bọ kuro lọwọ́ ewu igba isisiyi ati ti igba ti mbọ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Alabukún fun li ọmọ-ọdọ nâ, ẹniti Oluwa rẹ̀, nigbati a ba de, yio bá ni ṣíṣọna. Lõtọ ni mo wí fun nyin pe, on yio ti i jẹ olori lori gbogbo ohun ini rẹ̀.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun, awa ti o kún fun ohun jijẹ ati ohun mimu ọrun, nfi irẹlẹ ọkàn bẹbẹ lọdọ rẹ, jẹ ki a lè mâ dâbobo wa nipa ẹbẹ enia mimọ́ nâ, li iranti ẹniti awa ti ri ẹbun yi gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN WUNDIA MIMỌ ATI MARTIRI KAN.

Ipilẹṣẹ ti Misa Emi ti sòrọ ẹrí Rẹ niwaju awọn ọba, emi kò sì tiju : Emi ti nṣe aṣàro ninu ofin Rẹ, ti emi ti fẹ gidigidi. *Ps.* Alabukún fun li awọn ti npa ara wọn mọ́ lailabawọ́n ẹṣẹ li ọna nâ, ti o sì nrìn ninu ofin Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ẹniti, lârin ọpọlọpọ iṣẹ iyanu ti agbara rẹ, ti sọ ẹya alailéra ti awọn obirin di aṣẹgun nipa ikú nitori igbagbọ́ rẹ ; lojurere ânu rẹ tifunni, ki awa ti nṣe ọdún mimọ́ ti ọjọ́-ibí si aikú ti wundia rẹ mimọ́ ati martiri N..., ki o lè de ọdọ Rẹ nipa titọpasẹ iwa rere rẹ̀ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ekles. LI, 1).

Emi o fi ọpẹ́ fun ọ, Oluwa ati Ọba mi, emi o sì yìn ọ, Ọlọrun, Olugbala mi. Emi o fi ogo

fun orukọ Rẹ, nitoriti iwọ ti ràn mi lọwọ́, iwọ sì ti dâbobo mi. Iwọ ti gbà ara mi kuro ninu egbé, kuro ninu arekereke ahọ́n aisododo, ati kuro ninu ète awọn eleké, iwọ sì ti jẹ oluranlọwọ́ mi si awọn ti nfi ẹsùn sùn mi. Iwọ ti gbà mi là gẹgẹ bi ọpọ̀ ânu orukọ rẹ kuro lọwọ́ kiniu ti nke ramuramu, ti o sì ti mura tán lati pa mi jẹ; kuro lọwọ́ awọn ẹniti nwá lati pa mi; kuro ninu ipọnju ti nyí mi ka, kuro ninu ipá iná ti o yí mi ka, iná kò sì jó mi lârin iná; kuro ninu ibú ọrun-apâdi, kuro ninu ahọ́n aimọ́, kuro ninu ọ̀rọ̀ eké, kuro lọwọ́ ọba aisododo, ati kuro ninu ahọ́n agbadulumọ̀. Nitorinâ ọkàn mi yio mâ yìn Oluwa titid'oju ikú: Nitoriti Iwọ ti gbà awọn ẹniti ngbẹkẹle Ọ kuro ninu ewu, Oluwa, Iwọ sì ti gbà wọn là kuro lọwọ́ agbara awọn orilẹ-ède.

Graduali. Iwọ ti fẹ́ ododo, iwọ sì korira aisododo, nitorinâ ni Oluwa ṣe ta ororo ayọ̀ si ọ lori. Alleluia, alleluia. Lẹhin rẹ̀ li a o mu awọn wundia tọ̀ ọba lọ, pẹlu ayọ̀ li a o fi mu awọn egbẹ rẹ̀ olufẹ wá sọdọ rẹ. Alleluia.

Lẹhin ijọ ọsẹ Septuagesima, lipò Alleluia, *etc , a wí eyiti o tẹle yi pe :*

Traktu. Wá, iwọ iyawo Kristi, gbà adé ti Oluwa ti pèse silẹ fun ọ lati aiyeraiye wá, nitori ifẹ́ ẹniti iwọ ti ta èjẹ rẹ silẹ. Iwọ ti fẹ́ ododo, iwọ sì korira aisododo; nitorinâ ni Olọrun, Olọrun rẹ, ṣe ta ororo ayọ̀ si ọ lori jù awọn egbẹ rẹ lọ. Ninu èwa ati ọlá nla rẹ mâ rin lọ li alafia, ki o sì jọba.

Ihin rere (Mat. xxv, 1).

Nigbanà ni Jesu pa owe yi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ijọba ọrun yio dabi awọn wundia mẹwa, ti o mu fitila wọn, ti nwọn si lọ pade ọkọ iyawo ati iyawo li ọna. Marun ninu wọn jẹ aṣiwère, marun si ṣe ọlọgbọ́n. Awọn marun ti ise aṣiwère ti mu fitila wọn, ṣugbọn nwọn kò mu ororo pẹlu wọn. Ṣugbọn awọn ọlọgbọ́n ti mu ororo ninu kolobo wọn pẹlu fitila wọn. Bi ọkọ iyawo si ti pẹ, gbogbo wọn tõgbé, nwọn si sùn. Ṣugbọn li ọganjọ oru, a gbọ́ igbe nla kan, wipe : Wò o, ọkọ iyawo mbọ̀, ẹ lọ pade rẹ̀. Nigbanà ni gbogbo awọn wundia wọnyi dide, nwọn si tún fitila wọn ṣe. Ṣugbọn awọn aṣiwère wí fun awọn ọlọgbọ́n pe : Ẹ fun wa ninu ororo nyin, nitoriti fitila wa nkú lọ. Awọn ọlọgbọ́n da wọn lohùn wipe : Ki o má ba ṣe aito fun wa ati ẹnyin, ẹ kuku tọ̀ awọn ti nta lọ, ki ẹ si rà fun ara nyin. Ṣugbọn nigbati nwọn nlọ rà, ọkọ iyawo de ; awọn ti o ti mura tán si bá a wọlé lọ si ibi iyawo, a si ti ilẹkun. Nikẹhin li awọn wundia iyokùn si de, nwọn si wipe : Oluwa, Oluwa, ṣilẹkun fun wa. Ṣugbọn o da wọn lohùn wipe : Lõtọ ni mo wí fun nyin, emi kò mọ̀ nyin. Nitorinà ẹ mà ṣọ́ra, nitori ẹnyin kò mọ̀ ọjọ́ tabi wakati.

Ifitọrẹ. Lẹhin rẹ̀ li a o mu awọn wundia tọ̀ Ọba lọ, pẹlu inu-didùn ati ayọ̀ li a o ti mu awọn ẹgbẹ rẹ̀ olufẹ wá sodọ Rẹ ; a o mu wọn wọ̀ inu âtin Ọba lọ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, gbà èbun ti a nrú si ọ li ọjọ́ ọdún mimọ́ ti wundia ati martiri rẹ mimọ́ N.. , nipa èbẹ ẹniti awa nreti lati ri igbalà gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Jẹ ki oju ki o tì awọn onigberaga, nitoriti nwọn ti hùwa buburu si mi lainidi! Ṣugbọn emi o mâ ṣe aṣàro ninu ofin rẹ nigbagbogbo, ati ninu ilâna rẹ ti o kún fun ododo, ki oju ki o máṣe tì mi.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, jẹ ki a lè ràn wa lọwọ́ nipa ohun ijinlẹ mimọ́ rẹ ti awa ti gbà, ati nipa èbẹ wundia ati martiri rẹ mimọ́ N..., ki a lè mâ yọ̀ ninu âbo rẹ nigbagbogbo; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN WUNDIA MIMỌ KAN TI KÌ IṢE MARTIRI.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Iwọ ti fẹ ododo, iwọ sì korira aisododo: Nitorinâ ni Ọlọrun, Ọlọrun rẹ, ṣe ta ororo ayọ̀ si ọ lori jù awọn ẹgbẹ rẹ lọ. *Ps.* Ọkàn mi nsọ̀rọ̀ rere jade, ogo Ọba li emi sì nkọ orin mi si. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura

Ọlọrun igbalà wa, lojurere ânu rẹ gbọ́ ti

wa, ki o sì ifun wa, ki ọdún mimọ́ ti Wundia mimọ́ rẹ N..., ti a nfi tayọtayọ ṣe ki o lè rú inudidùn si ifọkansìn gbigbona soke ninu wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (2 Kor. x, 17).

Ẹnyin ará mi, ẹniti o ba nṣogo ninu ara rẹ̀, ki o mâ ṣogo ninu Oluwa, nitoripe kì iṣe ẹniti nyìn ara rẹ̀ li o yẹ fun ikàsi, bikoṣe eniti Ọlọrun yìn. Ki o lè wù Ọlọrun pe, ki ẹnyin ki o gbà mi diẹ ninu iwère mi! Ṣugbọn ẹ gbà mi. Nitoripe emi nfi owú Ọlọrun jowú si nyin; nitoriti emi ti fẹ́ nyin fun ọkọ kan, ti iṣe Kristi, lati mu nyin wá siwaju Rẹ̀ bi wundia mimọ́.

Graduali. Ninu ẹ̀wa ati ọlá nla rẹ mâ rìn lọ li alafia, ki o sì jọba. Nitori otitọ, ìwa tutù, ati ododo rẹ̀, li ọwọ́ ọtún rẹ yio mu ọ ṣe iṣiwaju li ọ̀na iyanu. Alleluia, alleluia. Lẹhin rẹ̀ li a o mu awọn wundia tọ̀ Ọba lọ; pẹlu inudidùn ati ayọ̀ li a o fi mu awọn ẹgbẹ rẹ̀ olufẹ wá sọdọ Rẹ.

Ihin rere.

O ri gẹgẹ bi ti Misa iṣiwaju.

Ifilọrẹ. Awọn ọmọbirin awọn ọba mbẹ ninu ogo Rẹ; li ọwọ́ ọtún Rẹ li Ayaba nâ gbé duro ninu aṣọ wura, ninu igunwà onirũru àwọ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, gbà ẹbọ ti awọn enia rẹ olufọkansìn

nrú si ọ li ọlá awọn wundia rẹ mimọ, lati ọwọ ẹniti awa njẹwọ pe a ti ri iranlọwọ gbà ninu iponju wa; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Awọn wundia marun, ti iṣe ọlọgbọn, ti mu ororo ninu kolobo wọn pẹlu fitila won: li oganjọ oru a si gbọ igbe nla kan, wipe: Wò o, ọkọ iyawo mbọ, ẹ lọ pade Kristi Oluwa li ọna.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, Iwọ ti fi ẹbun rẹ mimọ bọ awọn ará ile rẹ; awa mbẹbẹ lodọ rẹ, jẹ ki a lè mâ tù wa ninu nigbagbogbo nipa ẹbẹ Wundia mimọ nã, ọdún mimọ ẹniti a nṣe; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa Amin.

Lipò Epistoli ti iṣaju, a lè kà eyiti o tẹle yi.

Epistoli (1 Kor. VII, 24).

Ẹnyin ará mi, nipa ti awọn wundia, emi kò gbà aṣẹ lodọ Oluwa, ṣugbọn imọran kan li emi fi fun won, bi ẹniti o ri ânu Oluwa gbà lati jẹ olododo. Nitorinâ mo rò pe eyi dara nitori wahalà aiye (ati akokò kukuru ti a fifunni,) mo ni, o dara fun enia ki o wà bẹ. A ha ti dè ọ mọ aya ri bi? Máṣe wá ọna lati tú kuro. A ha ti tú ọ kuro lọwọ aya bi? Máṣe wá aya mọ. Ṣugbọn bi iwọ ba gbeyawo, iwọ kò dẹṣẹ; bi wundia ba si gbeyawo, on kò dẹṣẹ: Ṣugbọn irú wọnyi yio ni ipọnju ara. Ṣugbọn emi da nyin si. Nitorinâ eyi ni mo wí fun

nyin, ará, pe kukuru li akokò : o tó ki awọn ti o ni aya ki o dabi ẹnipe nwọn kò ni rara, ati awọn ti o sokún, bi ẹnipe nwọn kò sokún rara; awọn ti nyọ̀, bi ẹnipe nwọn kò yọ̀ rara ; awọn ti nrà, bi ẹnipe nwọn kò ni rara, ati awọn ti nlò aiye yi, bi ẹnipe nwọn kò lò o rara, nitori aworan aiye yi nkoja lọ. Ṣugbọn emi iba fẹ ki ẹnyin ki o wà laisi aniyàn. Ẹniti işe alaini aya, amâ tọju ohun ti işe ti Oluwa, bi on o ti şe wù Oluwa. Ṣugbọn ẹniti o ni aya, amâ tọju ohun ti işe ti aiye, bi on o ti şe wù aya rẹ̀ ; o sì pinya. Bẹ̀ gẹgẹ ni obirin ti kò ni ọkọ ati wundia amâ tọju ohun ti işe ti Oluwa, ki on ki o lè jẹ mimọ́ li ara ati li ẹmí, ninu Kristi Jesu Oluwa wa. .

MISA FUN OBIRIN MIMỌ KAN TI KÌ IṢE WUNDIA TABI MARTIRI.

Ipilẹşẹ ti Misa. Oluwa, emi mọ̀ pe ododo li idajọ rẹ, ati pe iwọ sì ti rẹ̀ mi silẹ gẹgẹ bi otito rẹ : jẹ ki ibẹ̀ru rẹ koja ninu ara mi, emi sì bẹ̀ru idajọ rẹ *Ps.* Alabukún fun li awọn ẹniti npa ara wọn mọ́ lailabawọn ẹ̀şẹ̀ li ọna nà, ti o sì nrìn ninu ofin Oluwa. Ogo ni fun Baba,

Adura.

Ọlọrun igbalà wa, lojurere ânu rẹ gbọ́ ti wa, ki o sì fifun wa, ki ọdún mimọ́ ti enia mimọ́ rẹ N..., ti a nfi tayọtayọ̀ şe, ki o lè rú inu didùn si ifọkansìn gbigbona soke ninu wa ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Owe Sal. xxxi, 10).

Tani yio ri obirin alagbara? Iye rẹ dabi ohun ti o ti ọna jijin rére, ati opin aiye wa. Okàn ọkọ rẹ gbẹkẹle e, bẹni on kì yio ṣe alaini èrè iṣẹ. Rere ni obirin nà yio mâ ṣe fun u, kì isì ṣe buburu ni gbogbo ojọ aiye rẹ. On ti wá irún-agutan ati ọgbọ, o sì ti ṣiṣẹ gẹgẹ bi ọnà ọwọ rẹ. O dabi ọkọ onisòwo, ti o mu onje rẹ lati ọna jijin rére wá. On a sì dide nigbati ilẹ kò ti imọ, o sì fi ohun èrè rẹ fun awọn ará ile rẹ ati onje fun awọn omọ-ọdọbirin rẹ. O kiyesi oko, o sì rà a, o sì fi èrè ọwọ rẹ gbìn ọgbà-ajara. O fi agbara di ara rẹ li àmure, o sì mu awọn apa rẹ lagbara. O mọ, o sì ri pe ọjà on dara. Fitila rẹ kì yio kú li oru. O fi ọwọ rẹ le ohun ti o lagbara, ọwọ rẹ sì di iránwu mu. O là ọwọ rẹ fun awọn talakà, o sì nà ọwọ rẹ si awọn alainí. On kì yio bẹru otutù tabi sno fun awọn ará ile rẹ, nitoripe gbogbo awọn ará ile rẹ li a wọ li aṣọ mejimeji. On sì ṣe gọgọwu fun ara rẹ, o fi aṣọ ọgbọ daradara ati elese aluko wọ ara rẹ. Ọkọ rẹ je olólá li enu-bode, nigbati o ba joko pelu awọn ijoyè ilẹ. O rán aṣọ daradara, o sì tà a, o sì fi ọjá àmure fun onisòwo ará Kanaani tà. Agbara ati èwa li aṣọ rẹ, on yio sì rerin li ojó ikẹhin. O là enu rẹ si ọgbọn. Ofin ãnu sì mbẹ lori ahọn rẹ: o tọju ìwa awọn ará ile rẹ daradara, kò sì je onje rẹ ninu olẹ. Awọn ọmọ rẹ sì dide, nwọn sì pè e li alabukún fun; ọkọ rẹ dide, o sì yìn i. Opọlọpọ awọn ọmọbirin ti kó ọrọ jọ; ṣugbọn iwọ ti ta gbogbo wọn yọ. Oju rere li ẹtan, èwa sì jasi asan: Obirin ti o bẹru Oluwa li a o yìn.

Fun u li eso iṣẹ ọwọ́ rẹ̀, jẹ ki iṣẹ ọwọ́ ara rẹ̀ ki o yìn i li ẹnu-bode.

Graduali. A ti dà ôre-ọfẹ si ọ li ète, nitorinâ li Olọrun mbukún fun ọ lailai. Nitori otitọ, ìwa tutù, ati ododo rẹ̀ li ọwọ́ ọtún rẹ̀ yio mu ọ ṣe iloṣiwaju li ọ̀na iyanu. Alleluia, alleluia. Ninu ẹ̀wa ati ọlá nla rẹ̀ mâ rìn lọ li alafia, ki o sì jọba. Alleluia.

Ihin rere (Mat. XIII, 44).

Nigbanà ni Jesu pa owe yi fun awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀ pe : Ijọba ọrun dabi iṣura ti a fi pamọ́ sinu oko kan ; ẹniti o ba ri i, o pa a mọ́, ninu ayọ̀ rẹ̀ o sì lọ, o tà ohun gbogbo ti o ni. o sì rà ilẹ̀ nâ. Ijọba ọrun tún dabi ọkọnri oniṣòwo kan ti nwá perli (tabi okuta) ti o dara gidigidi ; nigbati o ri perli oniyebiye lori kan, o lọ, o tà ohun gbogbo ti o ní, o sì rà a. Ijọba ọrun tún dabi àwọn kan ti a sọ sinu omi okun, ti o sì kó onirûru ẹja. Nigbati o kún, awọn apẹja fà a soke, nwọn joko leti okun, nwọn sì kó eyiti o dara sinu agbọ̀n, ṣugbọn nwọn kó buburu danù. Bẹ̀ gẹgẹ ni yio ri li opin aiye : Awọn Angẹli yio jade wá, nwọn o yà awọn enia buburu kuro ninu awọn ododo, nwọn o sì sọ wọn sinu iná ileru ; nibiti ẹkún ati ipahin keke yio gbé wà. Gbogbo nkan wọnyi ha yé nyin bi? Bẹ̀ni, o yé wa, Oluwa, ni nwọn da a lohùn. O sì wí fun wọn pe : Nitorinâ ni gbogbo akọwe, ti a kọ́ li ohun ti iṣe ti ijọba ọrun, ṣe dabi bâle ile kan, ti o nmu ohun titun ati ogbó jade ninu iṣura rẹ̀.

Ifitọrẹ. A ti dà ôre-ọfẹ sí ọ li ètè, nitorinâ li Ọlọrun mbukún fun ọ lailai.

Adura ti a kà jẹjẹ.

O ri bi ti Misa iṣiwaju.

Komunioni. Iwọ ti fẹ ododo, iwọ sì korira aiṣododo : nitorinâ li Ọlọrun, Ọlọrun rẹ, ṣe ta ororo ayọ̀ si ọ lori jù gbogbo awọn ẹgbẹ rẹ lo.

Adura lẹhin komunioni.

O ri gẹgẹ bi ti Misa iṣiwaju.

Fun opó mimọ́ kan, lipò Epistoli ti iṣaju, a kà eyiti o tẹle yi :

Epistoli (1 Timot. v, 3).

Ẹnyin ará mi olufẹ, bọwọ fun awọn opó, ti iṣe opó nitòtọ. Ṣugbọn bi opó kan ba ni ọmọ, tabi ọmọlọjọ, jẹ ki on ki o tète kọ́ wọn lati ṣakoso awọn ará ile ará wọn, ati lati fun awọn ôbi wọn li ohun nâ ti nwọn ti ri gbà lọwọ́ wọn ; nitoripe eyini li o jẹ atewogbà fun Ọlọrun. Ṣugbọn ki ẹniti iṣe opó nitòtọ, ti awọn enia sì ti kọ́ silẹ ki o mà gbẹkẹle Ọlọrun, ki o sì mâ duro ninu ẹbẹ ati adura li ọsan ati li oru. Nitoripe ẹniti o ba wà ninu aiye jijẹ, o ti kú bi o tilẹ jẹ pe o wà lâye. Ohun wọnyi ni ki iwọ pa lasẹ fun wọn, ki nwọn ki o lè gbé lailegàn. Ṣugbọn ẹnikẹni ti kò ba tọju awọn ará rẹ̀, ati nipataki awọn ará ile rẹ̀, o ti sẹ́ igbagbọ́ nâ, o sì buru jù keferi lọ. Ki opó nâ

ti a o yàn bi iranṣẹ ijọ awọn onigbagbọ) ki o máṣe dín ni ẹni ọgọ a ọdún, ẹniti o ti jẹ obirin ti ọkọ kan, ẹniti a sọrọ iṣẹ rere rẹ. ki a mọ bi o ba ti tọ awọn ọmọ rẹ si ọna rere, bi o ba ti gbà alejo si ile rẹ, bi o ba ti wẹ ẹsẹ awọn enia mimọ, bi o ba ti ràn awọn olupọnju lọwọ, bi o ba sì ti tẹramọ onirùru iṣẹ rere.

ỌJỌ IYÀSIMIMỌ TI ILE ỌLỌRUN

Li ọjọ 9n ati 18n ti oṣù Novemberi.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Bawo ni ihinyi ti lẹru to! ile Ọlọrun ni nitòtọ, ati ẹnu-ọna ti ọrun, a o sì mà pè e ni âfin Ọlọrun. *Ps.* Oluwa awọn ọmọ-ogun, bawo ni ibugbé mimọ rẹ yi ti dara to! Ọkàn mi fẹ gidigidi, o sì ṣe ọhaha lati wọ inu âfin Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ẹniti o nṣọ ọjọ ti iyàsimimọ ti ile mimọ yi di ọtún fun wa lọdọdún, ti o sì mâ jẹ ki a lè wá nigbagbogbo lati gbọ Misa, lojurere ânu rẹ gbọ adura awọn enia rẹ, ki o sì fifunni, ki gbogbo awọn ti o wọ inu ile mimọ rẹ lati bère ôre-ọfẹ lọwọ rẹ, ki o lè mâ ni ayọ lati ri wọn gbà; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ifihàn xxi, 2).

Li ọjọ wọnyi li emi Johanu ri ilú mimọ ni,

Jerusalemu titún, ti o nti orun sọkalẹ lati ọdọ Ọlọrun wá, ti a ti ṣe lọṣọ bi iyawo ti a ṣe lọṣọ fun ọkọ rẹ̀. Mo sì gbọ́ ohùn nla kan lati ori itẹ́ wá, ti o wipe : Ẹ wò ibugbé Ọlọrun pẹlu awọn enia, on yio sì mâ bá wọn gbé, nwọn o sì mâ jẹ enia rẹ̀, ati Ọlọrun ti mbá wọn gbé yio mâ jẹ Ọlọrun wọn. Ọlọrun yio sì nù omije gbogbo kuro loju wọn ; kì yio sì si ikú mọ́, tabi ìṣọfọ, tabi ikigbe, tabi irora ; nitori pe ohun atijọ ti kọja lọ. Eniti o sì joko lori itẹ́ nà wipe : Ẹ wò o, mo sọ ohun gbogbo di ọtún.

Graduali. Ihinyi li ọwọ́ Ọlọrun ti ṣe, òrọ ijinlẹ ti a kò lè sọ jade ni, ti kò sì lẹgàn. Oluwa, iwọ eniti egbẹ awọn Angẹli yi ka, lojurere ànu rẹ gbọ́ adura awọn ọmọ-ọdọ rẹ. Alleluia, alleluia. Emi o mâ foribalẹ fun Ọ ninu ile mimọ́ rẹ, emi o sì mâ fi ogo fun orukọ rẹ.

Ihin rere (Luk. xix, 1).

Nigbanà ni Jesu wọ inu Jeriko, o sì kọja làrin ìlú nâ, sì kiyesii, ọkọnri kan ti a npè ni Sakeu wà nibẹ̀ ; o jẹ olori awọn agbowode, o sì jẹ ọlọrọ̀. O sì nfẹ́ lati ri eniti ije Jesu, kò sì lè ri i nitori ìsududu awọn enia, ati nitoriti on jẹ enia kukuru. Nitorinà ni o sure siwaju, o sì gùn ori igi Sikamore, ki o lè ri i ; nitoriti yio kọja lọ nibẹ̀. Nigbati Jesu de ibẹ̀, o gbé oju soke, o ri i, o sì sọ fun u pe : Sakeu, yara sọkalẹ, nitoriti o tọ́ ki emi ki o wọ ile rẹ loni. O sì yara sọkalẹ, o sì fi ayọ̀ gbà A si ile rẹ̀. Gbogbo awọn ti o ri i, bẹ̀rẹsi ikùn, nwọn sì wipe : O lọ wọ́ lọdọ eniti ṣe ẹlẹṣẹ. Ṣugbọn

Sakeu dide, o sì wí fun Oluwa pe : Sawò o, Oluwa, idaji ohun iní mi li emi fifun awọn talakà, bi mo ba sì tàn ẹnikan jẹ, mo san a pada li isẹpo mẹrin. Jesu wí fun u pe : Loni ni igbalà wọ ile yi, nitoripe ọkan ninu awọn ọmọ Abrahamu ni on isẹ pẹlu. Nitori Ọmọ-enia de lati mâ wá ati lati mâ gbà awọn ti o ti nù là.

Ifitọrẹ. Oluwa Ọlọrun, ninu ododo ọkàn mi li emi ti fi gbogbo nkan wọnyi tọrẹ fun ọ, emi sì ti fi ayọ nla ri awọn-enia rẹ ti o wà nihinyi. Ọlọrun Israeli, mâ pa ifé rere yi mọ ninu wa.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, tẹwọgbà adura wa, pe nigbati a nrú ẹbun yi si ọ, ki a lè mâ yẹ nipa iránlọwọ rẹ lati ri ẽre ainipẹkun gbà ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Ile adura li a o mâ pè ile mi, ni Oluwa wí : ẹnikẹni ti o bère nibẹ o ri gbà, ẹniti o sì wá kiri o ri, ati fun ẹniti o kànkun, a o ṣí i silẹ.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun, Iwọ ẹniti o fi okuta alâye, ti a sì ti yàn, kọ ile ainipẹkun kan fun olá nla rẹ, fi iránlọwọ ore-ọfẹ rẹ fun awọn enia rẹ, pe bi Eklesia rẹ ti fẹ nipa ara rẹ, bẹ gẹgẹ ni ki o lè mâ pọsi i niti ohun iní ọrun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN MARIA WUNDIA MIMỌ

Ipilẹṣẹ ti Misa. A ki ọ Iyá mimọ́, iwọ ti o bi Ọba, ẹniti nṣakoso ọrun on aiye lai ati lailai. *Ps.* Ọkàn mi nṣọ ọ̀rọ rere jade, ogo Ọba li emi nkọ orin mi si. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Oluwa Ọlọrun wa, fifun awa ọmọ-ọdọ rẹ lati mâ jẹ alafia li ọkàn ati li ara nigbagbogbo, ati nipa ẹ̀bẹ Maria alabukúnfun lailai Wundia ki a lè mâ bọ kuro ninu ipọnju isisiyi, ki a si lè mâ jẹ alabapin ninu ayọ̀ ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Ekles. XXIV, 14).

Lati ipilẹṣẹ wá, ati ṣiwaju aiye li a ti dá mi; emi ki yio si dẹkun lati mâ wà lailai. Emi ti ṣe iransẹ niwaju Rẹ̀ ninu ibugbé mimọ́. Bayi ni a ti fi idi mi kalẹ ni Sioni, emi si ri ibi isimi mi ninu ilú mimọ́ nâ pẹlu ; agbara mi si mbẹ ni Jerusalemu. Emi si ti fi ẹsẹ̀ mi mulẹ ninu orilẹ-ède ọlọlá, ti awọn enia rẹ̀ ti Ọlọrun ti yàn li pín rẹ̀, ibugbé mi si wà ninu ijọ awọn Enia mimọ́.

Graduali Alabukún fun ni iwọ, iwọ si ye fun ọlá. Maria Wundia, iwọ ti o di Iyá Olúgbala wa laiso iwa Wundia rẹ̀ nù. Wundia, Iyá Ọlọrun, Ẹniti gbogbo ilẹ aiye kò lè gbà, O há ara rẹ̀ mọ́ ni inu rẹ bi enia. Alleluia, alleluia. Ọpá Jesse ti yọ itanná jade ; Wundia

kan ti bí Ẹniti iṣe Ọlọrun ati Enia. Ọlọrun ti tún funni li alafia, nipa dida ohun irẹlẹ pọmọ eyiti o tobi julọ ninu rẹ. Alleluia.

Lẹhin ijọ ọsẹ Septuagesima, lipò Alleluia, *etc., a kà eyiti o tẹle yi.*

Traktu. Mà yò, Maria Wundia, iwọ nikan li ẹniti o ti pa gbogbo adamò run. Iwọ ti o ti gbà ọrọ Angẹli gbọ, nigbati iwọ jẹ Wundia, iwọ ti bí Ẹniti iṣe Ọlọrun ati Enia, ati lẹhin ibimọ rẹ iwọ ti jẹ Wundia alailabawọn sibẹsibẹ. Iyá Ọlọrun, bẹbẹ fun wa.

Ihin rere (Luk. xi. 27).

Li akokò yi, bi Jesu ti mbá ijọ awọn enia sọrọ, obirin kan nahùn ninu ijọ, o si wí fun u pe : Alabukún fun li inu ti o bí ọ, ati ọmú ti iwọ mu. Ṣugbọn Jesu wipe : Nitòtọ, ki a kuku wipe : Alabukún fun li awọn ti ngbọ ọrọ Ọlọrun, ti nwọn si npa a mọ.

Ifitọrẹ. Mo kí ọ, Maria etc... *titide ọrọ* Jesu.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, nipa ânu Rẹ, ati nipa ẹbẹ Maria alabukún fun, lailai Wundia jẹ ki ọrẹ ẹbọ yi ki o lè mà gbà âsiki ati alafia fun wa nisisiyi ati titi aiye ti kò nipẹkun ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Komunioni. Alabukún fun li inu Maria Wundia, ti o ti bí Ọmọkọnri Baba aiyeraiye.

Adura lẹhin komunioni.

Oluwa, lẹhin igbati a ti ri irànlọwọ ti igbalà wa yi gbà, tifunni, awa mbẹbẹ lọdọ rẹ, ki a lè mâ dabobo wa nigbagbogbo nipa âbo ti Maria alabukún fun lailai Wundia, li ọlá ẹniti a ti rú ẹbọ yi si ọlá n!a rẹ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

MISA FUN IGBEYAWO.

Ipilẹṣẹ ti Misa. Ki Ọlọrun Israeli ki o da nyin pọ, ki O si mâ wà pẹlu nyin. On ti o ti ṣânu fun ọmọ meji bibi nikanṣoṣo : Oluwa, jẹ ki nwọn ki o mâ fi ibukún fun ọ sibẹsibẹ. *Ps.* Alabukún fun li awọn ẹniti npa ara wọn mọ lailabawọn èṣẹ li ọna nà, ti o si nrìn ninu ofin Oluwa. Ogo ni fun Baba, etc.

Adura.

Ọlọrun Olodumare ati alânu julọ, lojurere ânu rẹ gbọ ti wa, ki ohun nà ti a ṣe nipa iṣẹ, iranṣẹ wa ki o lè ri imuṣẹ rẹ gbà ibukún Rẹ : nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Epistoli (Efes. v, 22).

Ẹnyin ará mi, jẹ ki awọn aya ki o mâ teriba fun awọn ọkọ wọn, gẹgẹ bi fun Oluwa ; Nitoripe ọkọ ni iṣe olori aya, gẹgẹ bi Jesu-Kristi ti iṣe olori Eklesia (eyiti iṣe ara rẹ), Olugbala

eyiti On işe pẹlu. Nitorinâ gẹgẹ bi Eklesia ti tẹriba fun Kristi, bẹni ki awọn aya ki o mâ tẹriba fun awọn ọkọ wọn li ohun gbogbo. Ẹnyin ọkọ, ẹ fẹ awọn aya nyin, gẹgẹ bi Jesu-Kristi ti fẹ Eklesia rẹ, ti o si fi ara rẹ fun ikú nitori rẹ, ki On ki o lè sọ ọ di mimọ, lẹhin igbati O ti fi ibatisi omi wẹ ẹ mọ tán, nipa ọrọ iyè; ki On ki o lè mu u wá siwaju Rẹ li ogo, laini abawọn, tabi ohunjọ, tabi irú nkan bawọnyi, şugbọn ni mimọ ati lailegàn. Bẹ gẹgẹ ni o tọ ki awọn ọkọ ki o mâ fẹ awọn aya wọn gẹgẹ bi ara wọn tikalawọn Ẹniti o ba fẹ aya rẹ, o fẹ ontikalarẹ. Nitoriti kò si ẹnikan ti o ti korira ara rẹ ri, şugbọn o mâ bọ ọ, o si mâ kẹ ẹ, gẹgẹ bi Jesu-Kristi ti nşe fun Eklesia, nitoripe awa li èya ara rẹ, ẹran ara rẹ, ati egungun ara rẹ. Nitori idi yi nâ li ọkọnri yio şe fi baba ati iyá rẹ silẹ lati dapọmọ aya rẹ, awọn mejeji a si di ara kan. Eyi ni sakramenti nla, mo ni, ninu Kristi ati ninu Eklesia. Şugbọn ki olukuluku nyin ki o fẹ aya rẹ gẹgẹ bi ara rẹ tikalarẹ, ki aya ki o si bẹru ọkọ rẹ, ki o si bọwọ fun u.

Graduali. Aya rẹ yio dabi àjara eleso pupọ lârin ile rẹ Awọn ọmọ rẹ yio dabi ilahu ti igi olifi yí tabili rẹ ka. Alleluia, alleluia. Ki Olọrun ki o rán iranlọwọ rẹ si ọ lati Ibi mimọ rẹ wá, ati âbo rẹ lati Sioni wá. Alleluia.

Ihin rere (Mat. xix, 3).

Nigbanâ li awọn Farisi wá sodọ Jesu lati dán a wò, nwọn si wí fun u pe: O ha tọ si

nipa ofin ki ọkọnri ki o fi aya rẹ silẹ nitori idikidi kan bi? O da wọn lohùn wipe : Enyin kò ha ti kà a ninu iwe pe, ẹniti o dá enia lati ipilẹṣẹ wá, o dá a ti akọ ti abo, ati pe O sì ti wipe : Nitori idi yi li ọkọnri yio ṣe fi baba ati iyá rẹ silẹ, yio sì faramọ aya rẹ, awọn mejeji a sì di ara kan? Nitorinâ nwọn kì iṣe meji mọ, bikoṣe ara kan. Nitorinâ ohun ti Ọlọrun ba sopọ ki enia ki o máṣe yà a.

Ifitọrẹ Oluwa, iwọ ni mo gbẹkẹle ; mo ní, iwọ ni Ọlọrun mi ; igba mi mbẹ li ọwọ́ rẹ.

Adura ti a kà jẹjẹ.

Oluwa, awa mbẹbẹ lodọ rẹ, gbà ẹbọ ti a nrú si Ọ fun ide mimọ́ ti igbeyawo, ki iwọ tikalarẹ ki o sì ṣe amọ̀na awọn ẹniti Iwọ da pọ̀ nipa sakramenti yi ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

IBUKUN AWỌN ONIGBEYAWO.

Lẹhin Pater noster... saserdoti wi sori ọkọ ati iyawo pe :

Oluwa, lojurere ânu rẹ gbọ́ adura wa, ki o sì fi ôre-ọfẹ rẹ dâbobo sakramenti yi ti Iwọ ti ti dá silẹ fun ibisi awọn enia, ki ohun nâ ti a sopọ̀ nipa aṣẹ rẹ ki o lè di pipamọ́ nipa irànlọwọ́ rẹ ; nipasẹ Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Adura.

Ọlọrun, Iwọ ẹniti nipa agbara rẹ ti dá ohun

gbogbo lati inu asan wá, ati lẹhin igbati iwọ ti tò ipilẹṣẹ gbogbo aiye lẹṣẹṣẹ, ti iwọ sì ti dá enia li aworan rẹ, ti O sì fun u li obirin, ara ẹniti iwọ fi ẹran ara ọkọnri mọ, bi olurànlọwọ rẹ alailèyà, lati kọ wa pe lai kò tọ si nipa ofin lati yà awọn ti Iwọ ti sọ di ọkan nipa Sakramenti ti iwọ ti dá silẹ : Olorun, iwọ ti o ti yà ipò igbeyawo si mimọ nipa ọrọ ijinlẹ nla to bẹ, ti ipinhùn igbeyawo fi ṣe apẹrẹ idàpọṣọkan mimọ ti o wà làrin Kristi ati Eklesia rẹ : Olorun, nipa ẹniti a ti dà obirin pọmọ ọkọnri, ti O sì fun idàpọṣọkan wọn li ibukún nà, ti on nikan li a kò mu kuro nipa ijiyà èṣẹ akọṣẹ tabi nipa idalẹbi kikún omi; fi ojurere ânu wò ọmọ-ọdọbirin rẹ yi, ẹniti ntorọ âbo rẹ, nitoriti on yio dàpọmọ ọkọ rẹ ni igbeyawo nisisiyi ati ati titilọ. Jẹ ki âjaga rẹ ki o ṣe âjaga ifẹ ati alafia; ni mimọ ati nisọtọ ki o lè mà gbeyawo ninu Jesu-Kristi, ki o sì mâ jẹ alafarawé awọn obirin mimọ. Jẹ ki on ki o lè mà wù ọkọ rẹ gẹgẹ bi Rakeli; ki o lè jẹ amoye gẹgẹ bi Rebeka; ki o ni ẹmí gigún, ki o sì mà jẹ olọtọ gẹgẹ bi Sara. Jẹ ki olorisun èṣẹ ki o máṣe pin ninu iṣekiṣe rẹ. Jẹ ki on ki o lè mà duroṣinṣin ninu igbagbọ ati ofin rẹ; ki o mâ faramọ ọkọ rẹ nikan, ki o sì mâ sáfun gbogbo idàpọṣọkan ti o lodisi ofin rẹ. Jẹ ki on ki o lè dâbobo ìwa ailera rẹ nipa agbara ihùwa rere; ki o sì mâ jẹ ẹni-isaju, ati ọlọlá ninu iwa pẹlẹ, ki o sì mâ kọ iṣẹ rẹ ninu ẹkọ mimọ ti Jesu-Kristi. Jẹ ki o lè ri ọmọ pupọ gbà lọwọ rẹ, ki o sì mâ gbé ni mimọ ati lailegàn, ki o lè de ibi isimi awọn Enia mimọ li ijọba ọrun. Nikẹhin jẹ ki awọn mejeji wọnyi ki o lè mâ ri awọn ọmọ-ọmọ wọn

titide iran ẹkẹta ati ẹkẹrin, ki nwọn ki o sì lè de ogbó alafia.

Komunioni. Bayi ni ao bukún fun enia ti o bẹ̀ru Oluwa, bẹ̀ni ki iwọ ki o lè mâ ri ati ọmọ de ọmọ rẹ, ati alafia ninu Israeli.

Adura lẹhin komunioni.

Ọlọrun Olodumare, awa mbẹ̀bẹ lodọ rẹ, fi ôre ânu rẹ sìn olun ti iwọ ti dá silẹ nipa ipèse rẹ lọ, ki o sì mâ pa awọn nâ mọ́ li alafia gigún, ti iwọ ti dapọ̀ nipa idàpọ̀ṣọkan ti kò lodisi ofin ; nipase Jesu-Kristi Oluwa wa. Amin.

Lẹhin Ite Misa est, *saserdoti hà adura ti o tẹle yi sori tọkọ taya.*

Ki Ọlọrun Abrahamu, ti Isaaki ati ti Jakọbu ki o wà pẹlu nyin, ki o sì mu ibukún Rẹ̀ ṣẹ ninu nyin, ki ẹnyin ki o lè mâ ri awọn ọmọ-ọmọ nyin titide iran ẹkẹta ati ẹkẹrin, ati lẹhinna ki ẹnyin ki o lè jogún ìye ti kò nipẹkun nipa iràpadà Jesu-Kristi Oluwa wa, ẹniti o wà, ti o sì njọba pẹlu Ọlọrun Baba ninu ìṣọkan Ẹmí-Mimọ́, lai Ọlọrun kan, ainipẹkun. Amin.

AWỌN PSALMU MEJE TI IRÒNUPIWADA.

Psalmu 6. Domine ne in furore...

Oluwa, máṣe bá mi wí ni irunu rẹ, ki iwọ ki o má sì ṣe jẹ mi niyà ni ibinu rẹ.

Ṣânu fun mi, Oluwa, nitori alailéra li emi ; mu mi larada, Oluwa, nitoriti egungun mi wariri.

Ọkàn mi wà ninu iyonu gidigidi ; ṣugbọn iwọ, Oluwa, yio ti pẹ to ti iwọ o fi ràn mi lọwọ.

Yipada si mi, Oluwa, ki o sì gbà ọkàn mi à ; gbà mi là nitori ânu rẹ.

Nitoriti kò si ẹnikan ti o ranti rẹ ninu okú ; tani yio sì kọrin iyin rẹ ninu isà okú ?

Agara da mi ninu ikerora mi ; li oru gbogbo li emi nfi omi oju mi wẹ akete mi ; emi sì ti omije mi rin ibusùn mi.

Oju mi ṣokunkun nitori ibanujẹ ; mo sì da-rugbo tán làrin gbogbo awọn ọtá mi.

Ẹ lọ kuro lodọ mi, gbogbo ẹnyin ti nṣiṣẹ èṣẹ ; nitoriti Oluwa ti gbọ́ ohùn ẹkún mi.

Oluwa ti gbọ́ èbẹ mi ; Oluwa ti gbà adura mi.

Jẹ ki oju ki o tì gbogbo awọn ọtá mi, ki nwọn ki o sì fòya jojọ ; jẹ ki nwọn ki o pada kiakia, ki oju ki o si tì wọn.

Ogo ni fun Baba, ati fun Ọmọ, ati fun Ẹmí-Mimọ ; bi o ti wà li atetekọṣe, bẹni nisisiyi, bẹni yio sì mà ri nigbagbogbo, aiye ainipẹkun. Amin.

Psalmu 31. Beati quorum...

Alabukún fun li awọn ẹniti a dari aiṣe dede wọn jì ti a sì bò èṣẹ wọn mọlẹ.

Alabukún fun li ọkọnri nà ẹniti Oluwa kò kà èṣẹkèṣẹ kan si li ọrun, ati ninu ẹmí ẹniti ẹtàn kò si.

Nitoriti mo dakẹ, awọn egungun mi di ogbó, nigbati emi nkigbe li odidi ọjọ́.

Nitori li ọsán ati li oru, iwọ ti gbé ọwọ́ rẹ wiwuwo le mi lara; emi sì yipada si ọ ninu ibanujẹ mi, nigbati ẹgún ngún mi li ọkàn.

Emi ti jẹwọ ẹ̀ṣẹ mi fun Ọ, emi kò si fi aiṣododo mi pamọ́.

Emi ti wipe: Emi o jẹwọ aiṣodododo mi fun Oluwa; iwọ sì ti dari iwa buburu ti ẹ̀ṣẹ mi jì mi.

Nitori eyi li olukuluku enia mimọ́ yio mâ gbadura si ọ li akokò ti o yẹ; kikún omi pupọ̀ kì yio sì sunmọ́ ọdọ rẹ̀.

Iwọ ni ibi âbo mi ninu ipọnju ti o yí mi ka; Iwọ ti iṣe ayọ̀ mi, gbà mi là kuro lọwọ́ awọn ọtá ti o yí mi ka.

Emi yio fi oyé fun ọ, Emi yio sì kọ́ ọ li ọna ti iwọ o rìn, Emi o sì mâ tẹ̀ oju mi mọ́ ọ.

Ẹ kiyesara, ki ẹnyin kí o máṣe dabi ẹṣin tabi ibãka ti kò ni oyé. Fi ijanu kó awọn ti kò fẹ́ sunmọ́ ọdọ Rẹ li ẹnu. — Ọpọlọpọ ipọnju yio de si elẹṣẹ; ṣugbọn ẹniti o ba gbẹkẹle Oluwa ni ânu Rẹ̀ yio yí ka.

Ẹnyin olododo, ẹ mâ yọ̀ ninu Oluwa, ki ẹ sì mà hó ihó ayọ̀; ẹ mâ ṣogo ninu Rẹ̀, gbogbo ẹnyin ọlọkàn rere.

Ogo ni fun Baba, etc.

Psalmu 37. Domine, ne in furore tuo...

Oluwa, máṣe bá mi wí ninu irunu rẹ, bẹ̀ni kì yio má sì ṣe jẹ mi niyà n'nu ibinu rẹ.

Nitoriti ọfà rẹ ti gún mi lara, ọwọ́ rẹ sì kì mi wọ́ mọlẹ.

Kò si ibi ti o yè kôro ninu ẹran ara mi; bẹ̀ni kò si alafia mọ́ ninu egungun mi nitori ẹ̀ṣẹ mi.

Nitoriti awọn ẹṣẹ mi ti rekoja ori mi, ati bi ẹrù wiwuwo, nwọn sì wọ mi lì ọrùn.

Awọn egbò mi nrùn, nwọn sì dibajẹ nitori iwère mi.

Mo di otoṣi, gbogbo ara mi sì ntẹ; mo nrìn kakiri tânutânu li odidi ọjọ.

Nitoriti ìha mi kún fun idalara, kò sì si ibi ti o yè kòro ninu ẹran ara mi.

A ti pọn mi lọju, a sì ti rẹ mi silẹ gidigidi; ikerora ti ọkàn mi mu mi ké ramuramu.

Oluwa, gbogbo ifẹ mi mbẹ niwaju rẹ; ikerora mi kò farasin fun Ọ.

Ọkàn mi kún fun aisimi; agbara mi yè mi silẹ, imọlẹ oju mi kò sì si pẹlu mi mọ.

Awọn ọrẹ mi ati aladugbò mi ti ti mi silẹ, nwọn sì dide si mi.

Awọn ti o wà pẹlu mì duro li òkere réré, awọn ti nwá lati pa mì sì dẹkùn silẹ fun mi.

Awọn ti nwá lati ṣe buburu si mi npuró mọ mi, nwọn sì ngbìro ètan ni gbogbo ọjọ.

Ṣugbọn emi dabi aditi ti kò gbọ́ran, ati bi odi ti kò yà ẹnu rẹ.

Emi sì dabi eniа ti etí rẹ dí, ati li ẹnu ijánikoro kò si.

Nitori Iwọ li emi gbẹkẹle, Oluwa, Iwọ o gbọ́ ti emi, Oluwa Ọlọrun mi.

Nitori emi ti wí fun Ọ pe: Máṣe jẹ ki awọn ọtá mi ki o yọ̀ mi: Nigbati ẹsẹ̀ mi nyọ̀, nwọn ti ti igberaga sòrọ si mi.

Emi ti mura lati jiyà, ikànu mi sì mbẹ niwaju mi nigbagbogbo.

Nitoriti emi o jẹwọ aiṣedede mi, emi o sì mà rònu ẹṣẹ mi.

Ṣugbọn awọn ọtá mi wà lâye, nwọn sì lag-

bara jù mi lọ; awọn ti o korira mi laitọ̀ sì npòsi i.

Àwọn ti o nfi buburu san rere sòrọ mi ni buburu lẹhin, nitoriti emi nṣe ohun ti iṣe rere.

Oluwa Olọrun mi, máṣe kọ̀ mi silẹ; má sì ṣe lọ kuro lọdọ mi.

Yara lati rán mi lọwọ́, Oluwa Olọrun igbalà mi.

Ogo ni fun Baba, etc.

Psalmu 50. Miserere mei, Deus...

Olọrun, ṣànu fun mi gẹgẹ bi ọpọ̀ ânu rẹ; ki o sì pa aisedede mi rẹ gẹgẹ bi opọ̀ inu rere rẹ.

Wẹ̀ mi sibẹ̀sibẹ̀ kuro ninu aisedede mi, ki o sì wẹ̀ mi mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi.

Nitoriti emi mọ̀ aisedede mi; nigbagbogbo li ẹ̀ṣẹ mi sì mbẹ niwaju mi.

Iwọ nikanṣoṣo li emi ṣẹ̀ si; emi sì ṣe buburu niwaju rẹ, tobẹ̀ ti a o fi da ọ lare ninu ọ̀rọ rẹ, ti iwọ o sì fi ṣẹgun ti ọjọ́ idajọ.

Kiyesi i, a ti loyún mi ninu aisedede; iyá mi sì ti loyún mi ninu ẹ̀ṣẹ.

Nitori iwọ fẹ́ ododo, iwọ sì tú aṣiri ati ọ̀rọ ijinlẹ ti ọgbọ́n rẹ fun mi.

Fi eweko hisopu bù omi wọ́n mi, emi o sì mọ́; wẹ̀ mi, emi o sì fún jù snô tabi omi didi lọ.

Mu mi gbọ́ ọ̀rọ ayọ̀ ati itunu, awọn egungun mi ti a rẹ̀ silẹ yio mâ yọ̀.

Yí oju rẹ pada kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi, ki iwọ ki o sì pa gbogbo aisedede mi rẹ.

Olọrun, dá ọkàn mimọ́ sinu mi, ki iwọ ki o si tún ẹmí ododo ati iwa rere ṣe ninu ọkàn mi.

Máṣe ṣa mi ti kuro niwaju rẹ; ki o má sì ṣe gbà Ẹ̀mi-Mimọ́ rẹ lọwọ́ mi.

Fun mi li ayọ̀ igbalà rẹ pada, ki o sì mu mi lagbara nipa ẹmí ti o mu mi ṣe ohun rere tifẹtifẹ.

Èmi o mâ kọ́ awọn enia buburu li ọ̀na rẹ; awọn ẹlẹṣẹ yio sì mà yipada si ọ.

Ọlọrun, iwọ ti ise Ọlọrun igbalà mi, gbà mi kuro ninu ẹrù ẹ̀ṣẹ mi; ahọ́n mi yio sì mâ ti ayọ̀ yìn ododo rẹ.

Oluwa, ṣí mi li ète; ẹnu mi yio sì mâ sọ iyìn rẹ.

Nitoripe bi Iwọ ba ti fẹ́ ẹbọ, emi iba ti rú u si Ọ; ṣugbọn ẹbọ sisun kò jẹ atẹwọgbà fun Ọ.

Ẹbọ ti Ọlọrun ntẹ́ ni irobanujẹ ọkàn; Ọlọrun mi iwọ kì yio gàn ọkàn ibanujẹ ati irẹlẹ.

Oluwa, dà ibukún rẹ sori Sioni gẹgẹ bi ifẹ́ inu rere rẹ, ki a lè mọ odi Jerusalemu.

Nigbanâ ni iwọ o tẹwọgbà ẹbọ ododo, ọrẹ-ẹbọ sisun.

Nigbanâ ni a o fi akọ-malu rubọ lori altari rẹ.

Psalmu 101. Domine, exaudi orationem meam.

Oluwa, gbọ́ adura mi, ki o sì jẹ ki ikigbe mi ki o wá sọdọ rẹ.

Máṣe yí oju rẹ pada kuro lọdọ mi; li ijọkijọ́ ti mo ba wà ninu ipọnju, dẹ etí rẹ si mi. Li ọjọ́ ti mo ba kigbe pè Ọ, gbọ ti emi logan.

Nitoriti ọjọ́ mi nlọ bi ẽfin, egungun mi sì di gbigbẹ bi igi idaná..

A ti lù mi, ọkàn mi sì rọ bi koriko; nitoriti emi gbagbe lati jẹ onjẹ mi.

Nitori ohùn ikerora mi, egungun mi lẹmọ́ ẹran ara mi.

Mo dabi ẹiyẹ pelikani ni aginjù ; emi dabi owiwí ni ibugbé rẹ̀.

Emi nṣaisùn li oru, emi sì dabi olokoṣẹ anikanjẹ lori ile.

Awọn ọtá mi ngàn mi li ojojọ gbogbo ; awọn ti o ti nyìn mi nfi mi bú.

Emi ti jẹ èru bi onjẹ, emi sì ti da ohun mimu mi pọmọ omije mi. nitori ibinu ati irunu rẹ ; nitoriti iwọ ti gbé mi soke, ati lẹhinnâ iwọ ti jù mi mọlẹ.

Ojọ mi nlọ bi ojiji, emi sì nrọ bi koriko.

Ṣugbọn bi o ṣe ti iwọ ni, Oluwa, iwọ duro lai ati lailai ; iranti orukọ rẹ li a sì mâ pamọ lati irandiran.

Iwọ o dide, iwọ o sì ṣànu fun Sioni, nitoriti akokò nâ de, akokò lati ṣânu fun u.

Awọn iranṣẹ rẹ ṣe inudidùn si okuta Sioni, nwọn sì nkânu erupẹ rẹ̀.

Awọn keferi yio sì mâ bèru orukọ rẹ, Oluwa ; gbogbo ọba aiye yio sì mâ bèru ogo rẹ.

Nitoriti Oluwa ti gbé Sioni ró, yio sì farahàn ninu ogo rẹ̀ ; yio gbọ́ adura awọn onirẹlẹ ọkàn, kì yio sì gàn èbẹ wọn.

Jẹ ki a kọ nkan wọnyi sinu iwe fun iran ti mbọ̀, ki awọn enia ti a o dá ki o lè mâ yìn Oluwa.

Nitoriti O wò ilẹ lati òke ibi mimọ́ rẹ wá ; lati ọrun wá ni Oluwa ti bojuwò aiye ;

Lati gbọ́ ikerora awọn igbekun, lati gbà awọn ọmọ ti awọn ẹniti a ti pa là ;

Ki nwọn ki o lè sọ orukọ Oluwa ni Sioni, ati iyìn rẹ̀ ni Jerusalemu,

Nigbati awọn orilẹ-ède ati awọn ọba yio kó ara wọn jọ lati mâ sìn Oluwa pọ̀.

O wí fun Ọlọrun li igba agbara rẹ pe : jẹ ki emi ki o mọ bi ọjọ mi ti kere si.

Máṣe mu mi kuro ninu aiye li agbedemeji awọn ọjọ mi, iwọ ẹniti awọn ọdún rẹ duro lati irandiran.

Oluwa, ati ipilẹṣẹ wá ni iwọ ti fi ipilẹ aiye ṣọlẹ, awọn ọrun sì ni iṣẹ ọwọ rẹ.

Nwọn o ṣegbe, ṣugbọn iwọ o duro lailai; nwọn o gbó bi aṣọ.

Bi agbáda ni iwọ yio parọ wọn, a o sì pa wọn lawọda.

Ṣugbọn bakannâ ni iwọ nigbagbogbo awọn ọdún rẹ kì yio li opin.

Awọn ọmọ awọn iranṣẹ rẹ yio mâ bá Ọ gbé; irú-ọmọ wọn yio mà duro niwaju rẹ ati lailai.

Ogo ni fun Baba, etc.

Psalmu 129. De profundis.

Lati inu ibú osì mi wá li emi kigbe pè Ọ, Oluwa ; Oluwa, gbọ ohùn mi.

Jẹ ki eti rẹ ki o tẹ silẹ si ohùn ẹbẹ mi.

Oluwa, bi iwọ ba kiyesi aiṣedede wa, tani yio lè duro niwaju rẹ, Oluwa?

Ṣugbọn iwọ kún fun ânu, Oluwa, emi sì gbẹkẹle ọ nitori ofin rẹ.

Ọkàn mi gbẹkẹle ọ̀rọ̀ Rẹ; ọkàn mi ni ireti si Oluwa.

Lati afẹmọjumọ titide oru wá, jẹ ki Israeli ki o mâ ni ireti si Oluwa.

Nitoripe Oluwa kún fun ânu, a sì ri ọ̀pọlọpọ idande lọdọ Rẹ.

Ontikalarẹ yio sì dá Israeli nidè kuro ninu gbogbo ẹṣẹ rẹ.

Ogo ni fun Baba, etc.

Psalmu 142. Domine, exaudi orationem.

Oluwa, gbọ́ adura mi, jẹ ki etí rẹ ki o tẹ́ silẹ si ẹ̀bẹ mi gẹgẹ bi otitọ rẹ; gbọ́ ti emi gẹgẹ bi ododo rẹ.

Ki iwọ ki o má sì ṣe bá ọmọ-ọdọ rẹ lọ sinu idajọ, nitoriti kò si enia alàye kan ti a o dalare niwaju rẹ.

Gbọ́ ti emi, nitoriti ọ̀tá ṣe inunibini si ọkàn mi; o ti rẹ̀ emí mi silẹ; O ti mu mi joko li ibi òkunkun, bi awọn ti o ti kú pẹ.

Ẹ̀ru bà ọkàn mi nitori opin mi; o sì fò mi laiyà.

Èmi ranti ọjọ́ atijọ́; emi ṣe àṣaro iṣẹ rẹ gbogbo; emi nrònu iṣẹ ọwọ́ rẹ.

Emi nà ọwọ́ mi si O, ongbẹ Rẹ ngbẹ ọkàn mi gẹgẹ bi ilẹ gbigbẹ.

Oluwa, yara lati ràn mi lọwọ́, o rẹ̀ emí mi tán; máṣe yí oju rẹ pada kuro lọdọ mi, ki emi ki o mába dabi awọn ti o sọkalẹ lọ sinu isà okú.

Mu mi gbọ́ ohùn ânu rẹ ni kutukutu owurọ̀: nitori iwọ ni emi gbẹkẹle. Mu mi mọ̀ ọ̀na ti o tọ́ ki emi ki o ba tọ̀, nitori iwọ ni emi gbé ọkàn mi soke si.

Gbà mi kuro lọwọ́ awọn ọ̀tá mi, Oluwa, ọdọ rẹ li emi sá si.

Kọ́ mi lati ṣe ifẹ́ rẹ, nitori iwọ li Ọlọrun mi.

Ẹ̀mí rere rẹ yio tọ́ mi si ọ̀na ìwa rere ati ododo.

Oluwa, fun li ìye nitori orukọ rẹ, gẹgẹ bi ododo rẹ. mu ọkàn mi kuro ninu ipọnju, ati ninu ânu rẹ pa awọn ọ̀tá mi run;

Ki o sì pa awọn ti o pọ́n ọkàn mi lojù run, nitoripe iranṣẹ rẹ li emi ṣe.

Ogo ni fun Baba, etc.

LITANI AWỌN ENIA MIMỌ

Gẹgẹ bi a ti kà a li ojọ ẹbẹ

Oluwa; ṣânu fun wa.
Kristi; ṣânu fun wa.
Oluwa; ṣânu fun wa.
Kristi; gbọ́ ti wa.
Kristi; gbàadura wa.
Olọrun Baba ọrun; ṣânu fun wa.
Olọrun Ọmọ, Olurapada araiye; ṣânu fun wa.
Olọrun Ẹmí-Mimọ́; ṣânu fun wa.
Ẹni-Mẹtalọkan mimọ́, ti iṣe Olọrun kanṣoṣo; ṣânu fun wa.
Maria mimọ́,
Iyá mimọ́ Olọrun,
Wundia mimọ́ julọ ninu awọn Wundia,
Mikaeli mimọ́,
Gabrieli mimọ́,
Rafaeli mimọ́,
Gbogbo ẹnyin Angẹli ati Olori awọn Angẹli, ẹ gbadua fun wa.
Gbogbo ẹnyin ẹgbẹ mimọ́ ti awọn Ẹmí alabukún fun, ẹ gbadua fun wa.
Johani-Baptisti mimọ́, gbadua fun wa.
Josefu mimọ́, gbadua fun wa,
Gbogbo ẹnyin Baba nla ati Woli mimọ́, ẹ gbadua fun wa.
Peteru mimọ́,
Paulu mimọ́,
Anderu mimọ́,
Jakọbu mimọ́,
Johanu mimọ́,
Toma mimọ́,

Gbadua fun wa.

Gbadua fun wa.

Jakọbu mimọ́,
Filipi mimọ́,
Bartolomi mimọ́,
Mateu mimọ́,
Simoni mimọ́,
Tadeu mimọ́,
Matia mimọ́,
Barnaba mimọ́,
Luku mimọ́,
Marko mimọ́,

Gbadua fun wa.

Gbogbo ẹnyin Apostoli ati Efangelisti mimọ́, ẹ gbadua fun wa.
Gbogbo ẹnyin Ọmọ-ẹhin mimọ́ ti Oluwa wa, ẹ gbadua fun wa.
Gbogbo ẹnyin Ọmọ ọwọ alaiṣẹ-alairo mimọ́, ẹ gbadua fun wa.
Stefanu mimọ́, gbadua fun wa.
Lorensu mimọ́, gbadua fun wa.
Finsenti mimọ́, gbadua fun wa.
Fabiani ati Sebastiani mimọ́, ẹ gbadua fun wa.
Johanu ati Paulu mimọ́, ẹ gbadua fun wa
Kosmo ati Damiano mimọ́, ẹ gbadua fun wa.
Jerfasi ati Protasi mimọ́, ẹ gbadua fun wa.
Gbogbo ẹnyin Martiri mimọ́, ẹ gbadua fun wa.

Silfesteri mimọ́.
Gregori mimọ́,
Ambrosi mimọ́,
Agustini mimọ́,
Jeronimo mimọ́,
Martini mimọ́,
Nikolau mimọ́,

Gbadua fun wa

Gbobgo ẹnyin Bisọpu mimọ́ ati Onijẹwọ mimọ́ Ọlọrun, ẹ gbadua fun wa.

Gbogbo ẹnyin Olukọ́ni mimọ́ ti Eklesia,
ẹ gbadua fun wa.
Antoni mimọ́,
Beneditu mimọ́,
Bernadu mimọ́,
Domingɔ mimọ́,
Fransisku mimọ́,
Gbogbo ẹnyin Saserdoti ati Lefiti mimọ́,
ẹ gbadua fun wa.
Gbadua fun wa.
Gbogbo ẹnyin Ọkọnri ẹlẹhá mimọ́, ẹ ghà etc.
Maria Magdalena mimọ́, gbadua fun wa.
Agata mimọ́,
Lusia mimọ́,
Agnesi mimọ́,
Sesilia mimọ́,
Katarina mimọ́,
Anastasia mimọ́,
Gbogbo ẹnyin Wundia ati Opó mimọ́,
ẹ gbadua fun wa.
Gbadua fun wa.
Gbogbo ẹnyin Enia mimọ́ Ọlọrun,
ẹ bẹ̀bẹ̀ fun wa.
Ṣânu fun wa ; Dariji wa Oluwa.
Ṣânu fun wa ; Gbà dura wa Oluwa.
Kuro ninu ohun buburu gbogbo,
Kuro ninu gbogbo ẹ̀ṣẹ̀,
Kuro ninu ibinu rẹ,
Kuro lọwọ́ ikú ojiji ti a kò sì ri tẹlẹ,
Kuro ninu ikẹkùn èṣu,
Kuro ninu ibinu, ikorira, ati gbogbo
ifẹ̀ buburu,
Kuro lọwọ́ ẹmí iṣepansaga,
Kuro ninu manamana ati iji,
Kuro ninu ipọ́nju iṣẹlẹ,
Kuro ninu ajakalẹ-arun iyan ati
ogun,
Oluwa, gbà wa là.

Kuro ninu ikú ainipekun,
Nipa òrọ ijinlẹ ti Isọdi enia rẹ mimọ,
Nipa wiwá rẹ,
Nipa ibí rẹ,
Nipa ibatisi ati àwẹ rẹ mimọ,
Nipa agbelebu ati ijiyà rẹ,
Nipa ikú ati sisìn rẹ,
Nipa ajinde rẹ mimọ,
Nipa igoke rè òrun rẹ ti o kún fun iyanu,
Nipa wiwá Emi-Mimọ, Olutunu,
Li ọjọ idajọ,
Eleṣẹ Awa mbẹ O, gbọ ti wa.
Fiyesi i lati da wa si,
Fiyesi i lati dari èṣẹ wa ji wa,
Fiyesi i lati yi wa pada si irònupiwada tôtọ,
Fiyesi i lati ṣakoso Eklesia rẹ mimọ ati lati pa a mọ,
Fiyesi i lati pa Papa mimọ ati gbogbo onirùru ijoyè ti Eklesia mọ ninu isìn rẹ mimọ,
Fiyesi i lati rẹ awọn ọtá ti Eklesia mimọ silẹ,
Fiyesi i lati fun awọn ọba ati awọn ọmọ-alade kristiani li alafia ati isọkan tôtọ,
Fiyesi i lati fun gbogbo awọn enia kristiani li alafia ati isọkan igbagbọ,
Fiyesi i lati fi èsè wa mule ati lati pa wa mọ ninu isẹ isìn rẹ mimọ,
Fiyesi i lati gbé ọkàn wa soke sì fifẹ ohun inú òrun,

Fiyesi i lati fi ohun iní ainipẹkun
san a fun gbogbo olôre wa,
Fiyesi i lati gbà ọkàn wa, ti awọn
ará wa, ti awọn ibatan ati olôre
wa kuro ninu egbé ainipẹkun,
Fiyesi i lati fun ilẹ li onirûru eso
ati lati mà pa wọn mọ́,
Fiyesi i lati fi isimi ainipẹkun fun
gbogbo awọn onigbagbọ́ ti o ṣe
alaisi,
Fiyesi i lati fi ojurere gbọ́ ti wa,
Ọmọ Ọlọrun.
Ọdọ-agutan Ọlọrun ti o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ,
Darijì wa Oluwa.
Ọdọ-agutan Ọlọrun ti o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ,
Gbà'dura wa Oluwa.
Ọdọ-agutan Ọlọrun ti o kó ẹ̀ṣẹ̀ aiye lọ;
Ṣànu fun wa.
Kristi; gbọ́ ti wa.
Kristi; gbà adura wa.
Oluwa; ṣànu fun wa.
Kristi: ṣànu fun wa.
Oluwa: ṣànu fun wa.
Baba wa ti mbẹ li ọrun, etc.

Psalmu 69. Deus in adjutorium.

Ọlọrun, wá ràn mi lọwọ́; Oluwa, yara lati ràn mi lọwọ́.

Jẹ ki oju ki o tì awọn ti nwá lati pa mi, ki nwọn ki o sì dãmu.

Ki nwọn ki o pada sẹhin, ki oju ki o sì tì awọn ti nfẹ́ buburu si mi.

Ki nwọn ki o pada lọgan ti awọn ti itiju, awọn ti o nsọ̀rọ̀ ẹgan ati ebú si mi.

Ki gbogbo awọn ti nwá Ọ ki o mà yọ, ki inu wọn ki o sì mà dùn niti rẹ. Ki irú awọn ti nfẹ igbalà ti o ti ọdọ rẹ wá ki o mà wí nigbagbogbo pe : Ki a yìn Olọrun logo.

Ṣugbọn òtoṣi ati talàkà li emi : Olọrun, ràn mi lọwọ.

Iwọ li Oluranlọwọ ati Olugbala mi ; Oluwa, máṣe pẹ titi.

Ogo ni fun Baba, etc.

℣. Gbà awọn iranṣẹ rẹ là.

℟. Awọn ti o ngbẹkẹle Ọ, Olọrun mi.

℣. Ki iwọ ki o jẹ ile iṣọ agbara fun wa.

℟. Si awọn ọtá wa.

℣. Máṣe jẹ ki ọtá ki o bori wa li ohunkohun.

℟. Bẹni ki o má sì ṣe jẹ ki enia buburu ki o wá sodọ wa lati pani lara.

℣. Oluwa, máṣe hùwa si wa gẹgẹ bi ẹṣẹ wa.

℟. Bẹni ki iwọ ki o má sì ṣe san a fun wa gẹgẹ bi ẹṣẹ wa.

℣. Ẹ jẹ ki a gbadura fun Papa mimọ wa N...

℟. Ki Oluwa ki o pa a mọ, ki o fun u li emi gigún ati alafia fori ilẹ aiye, ki o má sì ṣe fi i le awọn ọtá rẹ lọwọ.

℣. Ẹ jẹ ki a gbadua fun awọn olòre wa.

℟. Oluwa, fiyesi nitori oruko rẹ lati fi iye ainipẹkun san a fun gbogbo awọn ti o nṣòre fun wa. Amin.

℣. Ẹ jẹ ki a gbadua fun awọn onigbagbọ ti o jẹ alaisi.

℟. Oluwa, fun wọn li isimi ainipẹkun, ki imọlẹ ainipẹkun ki o sì mà mọlẹ si wọn.

℣. Jẹ ki nwọn ki o mà simi li alafia.
℟. Amin.
℣. Ẹ jẹ ki a gbadua fun awọn ará wa ti kò si nihinyi
℟. Olorun mi, gbà awọn iranṣẹ rẹ ti o ngbẹkẹle Ọ là.
℣. Oluwa, ràn iranlọwọ si wọn lati ibi mimọ rẹ wá.
℟. Ki o si dàbobo wọn lati Sioni wá.
℣. Oluwa, fi ojurere gbọ́ adura mi.
℟. Jẹ ki ikigbe mi ki o wá sodọ rẹ.
℣. Ki Oluwa ki o wà pẹlu nyin.
℟. Ati pẹlu ẹmí rẹ.

Adura

Olọrun, ìwa ẹniti iṣe lailai lati mà ṣànu ati lati mà darijini, fi ojurere gbà ẹbẹ wa, pe nipa ânu inu rere rẹ ki awa ati gbogbo awọn ọmọ-ọdọ rẹ ti a fi ẹ̀wọn ẹ̀ṣẹ dè nidè ki o lè bọ kuro ninu rẹ̀. Oluwa, awa mẹbẹ lodọ rẹ, lojurere ânu rẹ gbọ́ adura irẹlẹ wa, ki o si dariji awọn ti o jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn niwaju rẹ, ki awa ki o lè ri idarijì ẹ̀ṣẹ wa ati alafia gbà lọwọ́ ânu rẹ. Amin.

Adura si Angẹli olutọju wa.

Angẹli Ọlọrun, iwọ ti iṣe Olutọju mi, tàn imọlẹ si mi, ki o ṣamọna mi, ki o si ṣakoso emi otọsi ẹlẹṣẹ, ti Ọlọrun ninu ânu rẹ ti fi aniyàn rẹ ṣọ.

Adura ti a bùn indulgensi si lori.

Jesu, oninu tutù ati onirẹlẹ ọkàn, sọ ọkàn mi dabi tirẹ.

Ọkàn tutù ti Jesu, jẹ ifẹ mi.

Ọkàn tutù ti Maria, jẹ igbalà mi.

Iyìn ati ibukún ni fun Jesu ninu Sakramenti mimọ ti Altari.

Maria, iwọ ẹniti a loyún laini abawọn ẹṣẹ akọṣẹ, gbadua fun awa ti o ntọ Ọ wá.

Jesu, Ọlọrun mi, mo fẹran rẹ jù nkan gbogbo lọ.

Jesu, ṣânu fun mi.

Ọkàn mimọ ti Jesu, ṣânu fun wa.

Ọkàn alailabawọn ẹṣẹ ti Maria, gbadua fun wa.

Ogo ni fun Baba, etc.

Adura ti a lè kà nigba abensan ati nigbati a bẹ Oluwa Jesu-Kristi wò ninu Sakramenti mimọ ti Altari.

Oluwa Jesu-Kristi, Olurapada ọkàn mi, Iwọ ẹniti o ti wù nitori ifẹ nla rẹ si awọn enia lati fi ara ati ẹjẹ rẹ iyebiye silẹ fun wa ninu Sakra-

menti mimọ́ ti Altari, mo gbagbọ́ pe Iwọ wà nìwayiwa ninu Sakramenti mimọ́ julọ yi, mo ti irẹlẹ ọkàn foribalẹ fun Ọ, mo si dupẹ fun Ọ nitori gbogbo ôre ti iwọ ti ti fun mi, ati nipataki nitori idásilẹ Sakramenti mimọ́, julọ yi. Bi iwọ ti jẹ olorisun gbogbo ibukún, mo bẹbẹ lodọ rẹ lati dà ibukún rẹ sori mi li ọjọ́ oni, ati sori gbogbo awọn eniti a ngbadua fun. Ki ohunkohun ki o máṣe da ibukún rẹ duro lati de si mi, mo bẹ Ọ lati lé gbogbo eyiti o ṣaiwù Ọ jade kuro ninu ọkàn mi: dari èṣe mi ji mi, Olorun mi, nitoriti emi korira wọn tokàntokàn nitori ifẹ rẹ; wẹ ọkàn mi mọ́, ki o sọ ọ di mimọ́, ki Ó sì dà irú ibukún nâ sori mi ti iwọ ti fifun awọn ọmọ-ẹhin rẹ, nigbati iwọ ti goke rè orun; fun mi li irú ibukún nâ ti o lè yí mi pada, ti o lè yà mi si mimọ́ fun ọ, ti o lè mà da mi pọmọ́ Ọ patapata, ti o lè kún mi fun Emí rẹ, ti o si lè jẹ itọwò awọn ibukún nâ fun mi, ti Iwọ ti pèse silẹ fun awọn ayanfẹ rẹ li orun rere. Gbogbo nkan wọnyi li emi ntọrọ li orukọ Baba, ati Ọmọ ati Ẹmi-mimọ́. Amin.

Itunṣe ileri iyanisoto fun Maria Wundia mimọ́.

Maria mimọ́ alagbawi ati iyá wa olufẹ, awa ti o l'alafia lati jẹ ọmọ rẹ ayanfẹ, inu wa dùn gidigidi lati mâ wá si èsè altari rẹ losoṣù, lati jumọ túnileri ifẹ wa ṣe, nipa eyiti awa ti yá ara wa sọtọ fun isìn rẹ. Fiyesi i lati tún gbà ifitọrẹ gbogbo ara wa; tirẹ ni gbogbo irònu

wa, ifę́, iṣẹ ati gbogbo ọjọ́ aiye wa. Kiyesi i, awa wólẹ lẹba ẹsẹ rẹ lati fi idupẹ ti ọkàn wa kún fun hàn fun Ọ nitori anfani pataki ti Iwọ ṣe fun wa nipa gbigbà wa sinu iye awọn ọmọ rẹ olufẹ, ati nitori gbogbo ôre-ọfẹ ti iwọ ti gbà fún olukuluku wa ninu oṣù ti o kọja yi. Iyá alânu julọ ninu awọn iyá, fiyesi i lati pari iṣẹ ti iwọ bèrẹsi ṣe ninu wa, nipa bibẹ Ọmọ rẹ Jesu ki Ó fun wa ni ôre-ọfẹ lati dahùnsi ilẹ́ gbigbona ati ọ̀pọlọpọ ôre Rẹ̀.

Maria mimọ́, dari ijafara ati ainâni wa fun isìn rẹ jì wa, ti awa ti jẹbi ninu oṣù ti o kọja yi, ki o sì tubọ̀ dà ibukún rẹ sori wa. Lôtọ ni ọmọ alaimore li awa nṣe, ṣugbọn iyá ha lè kọ̀ ọmọ rẹ̀ silẹ, nigbati o ti omije irònupiwada ati ibanujẹ ọkàn tọ ọ wá bi? Bí awa kò ba ye fun ôre rẹ, Maria oninurere, ranti pe iwọ ni Wundia alânu, ibi asási awọn ẹlẹṣẹ, iyá ânu, ati iyá wa oninu rirọ̀. Awa ọmọ rẹ wólẹ lẹba ẹsẹ rẹ nisisiyi lati lò agbara didùn si ọkàn rẹ ti iyá, ki iwọ ki o lè fi ojurere gbọ́ ti wa.

Wundia mimọ́ julọ ninu awọn Wundia, lojurere ânu rẹ gbà awa ọmọ rẹ nisisiyi ati titilọ, ki o fi inu rere tọju wa lati ori itẹ rẹ ti o logo, ki o sì dàbobo wa kuro lọwọ ọ̀tá ti igbalà wa. Awa gbé itùnu ati ẹdùn wa, ireti ati ibẹ̀ru wa kalẹ niwaju rẹ. Ninu ibanujẹ wa iwọ jẹ ayọ̀ wa; ninu ijà wa si ikọlù ẹṣù ati aiye buburu yi ki iwọ ki o jẹ asà wa, ninu gbogbo ohun idáwọle wa ki o jẹ igbimọ̀ wa, ati ninu gbogbo aini wa ki o jẹ ibi asálà wa. Fi ojurere wò wa niwọn gbogbo ọjọ́ aiye wa. Jẹ ki ifẹ́ wa si Jesu ati si ọ ki o mâ pọ̀ si i lojojumọ, ki a sì lè mọ̀ asan ohun ti aiye yi sibẹsibẹ, ki awa

máṣe fi ara wa fun wọn. Gbà ôre-ọfẹ fun wa lati mâ ṣe afarawé ìwa rere rẹ. ati lati tọpasẹ rẹ ninu ìwa mimọ ti ọkàn ati ti ara, ninu ìwa tútù. sùru. ìwa pẹlẹ, irẹlẹ ifẹ́ni ati itẹriba fun ifẹ́ Ọlọrun Nikẹhin mu wa durosinsin ninu ilọkansìn rẹ, ki o má sì ṣe fi wa silẹ li akokò ikú, pe lẹhin igbati awa ti bọlá fun Ọ, ti a sì ti sìn ọ bi o ti yẹ li aiye yi, ki gbogbo wa ki o lè ri afafia lati ba Ọ dapọ li ọrun rere. Amin.

Itunṣe awọn ileri Ibatisi.

Ọlọrun mi, kiyesi i. mo wólẹ lẹba ẹsẹ rẹ lati dupẹ lowó rẹ nitori ôre-ọfẹ Ibatisi ti Iwọ ti fi fun mi. A ti bí mi li ọmọ ibinu ati ọmọ eṣù. Ninu ìwa nâ, emi kò lè pin ninu alafia awọn Enia mimọ. Iwọ nikan. Ọlọrun mi, l'o mu ki a bí mi ninu Eklesia katolika, ti o sì fun mi li ôre-ọfẹ lati gbà Ibatisi mimọ. Lojukannâ ti mo ti gbà a, Iwọ tún fun mi ni gbogbo aṣẹ si ogún ọrun rere.

Bi a ti fi àmi awọn ọmọ Ọlọrun sà iwaju ori mi, ti mo sì ti ní Jesu-Kristi bi arakọuri ati olori mi, kò yẹ rara ki emi tún di ẹrú eṣù. Èṣe ti emi fi bá Emi-mimọ ninu jẹ, ti mo sì ti lé E kuro ninu ọkàn mi?

Kini aṣọ ìwa alailẹṣẹ mi ti dà? Mo ti wọ ọ sinu ẹgbin èṣẹ. Ṣugbọn Ọlọrun mi, Iwọ l'ó ti wẹ ẹ mọ loni ninu ẹjẹ rẹ mimọ, o sì fún jù ẹgbọn owu lọ. Awọn ileri Ibatisi ti mo ti bajẹ li emi nà túnṣe tifẹtifẹ ati tọkàntọkàn loni.

Ọlọrun mi, mo gbà Ọ gbọ tọkàntọkàn igbagbọ mi yi yio sì jẹ ilàna ihùwa rere.

Afẹ, ẹtan ati apejọ ibajẹ, nkan lasan li ẹnyin fun ọkàn mi, mo sì gàn nyin. Iwọ Ihin rere ti Jesu-Kristi, Iwo li ayọ̀ mi. Ile mimọ́ t'Ọlọrun, iwọ li ibugbé mi ayanfẹ; ẹnyin olododo ti aiye yi, emi yio mà wá ba nyin korin iyìn si Ọlọrun ninu rẹ̀. Nigbati wakati ikẹhin mi ba sì de, awọn Angẹli yio gbà mi pẹlu nyin sinu ibugbé aiyeraiye, nibiti a o gbé ri Ọlọrun lojukoju titilai, ẹniti o ti wá gbé inu ọkàn wa li ọjọ́ oni ti o dara yi. Nitorinà ni mo bura niwaju ijọ enia wọnyi ati niwaju altari yi pe: Mo kọ̀ eṣù silẹ pẹlu gbogbo iṣẹ ati irera rẹ̀, mo sì fi gbogbo ara mi fun Ọ Ọlọrun mi, lati mà sìn Ọ niwọn gbogbo ọjọ́ aiye mi nipa igbagbọ́, ireti, ifẹ́ni ati nipa tìti igbọ́ran pa gbogbo ofin rẹ mọ́. Amin.

Lẹhinnâ a fi ọwọ́ ọtún le iwe mimọ́ lori, a sì wipe:

Mo kọ̀ eṣù silẹ pẹlu gbogbo iṣẹ ati irera rẹ̀, mo sì ṣe ileri lati mâ topasẹ Jesu-Kristi lati mâ jẹ ọmọ ti Eklesia katolika titi doju ikú mi, ati lati mà pa gbogbo ofin Ọlọrun ati ti Eklesia mọ́ bi o ti yẹ. Amin.

Iṣe iyanisọtọ fun Maria Wundia mimọ́.

Maria mimọ́, iyá oninurere ati olufẹ, awa wá lati yà ara wa sọtọ fun ọ patapata li ọjọ́ oni ti o dara yi, ti awa ti li alafia lati gbà Oluwa wa Jesu-Kristi, Ọmọ rẹ̀, sinu ọkàn wa lârin ekini ninu komunioni mimọ́, awa sì fi àiya, ọkàn, ara wa, ati ohunkohun ti o jẹ ti wa gẹgẹ bi o ti ri fun Ọ. Fiyesi i lati gbà wa sabẹ âbo

rẹ, Iwọ Iyálode ọrun on aiye. Bi iwọ ti jẹ iyá Olọrun, iwọ lè ṣe ohunkohun ; Jesu, ti iṣe Ọmọ Baba aiyeraiye ati tirẹ, o gbó èbẹ rẹ nigbagbogbo ninu ânu Rẹ ailopin. Ọmọ rẹ li awa nṣe, Maria mimọ, máṣe gbagbe eyi nitorinâ li awa ṣe fi igbẹkẹle girigiri fi ara wa le ọ lọwọ. Iwọ kì yio mu oju rẹ kuro lọdọ wa lati jẹ kì awa ṣubu sinu ibú aiyeraiye ; agbẹdọ, ọkàn rẹ bi iyá kì yio lè jẹ ki o ri bẹ lailai. Alailera li awa, a o sì ṣegbé lârin ewu ti o yí wa ka, bi iwọ kò ba ràn wa lọwọ. Iwọ mọ pe ojó wa dabi okun ti afẹfẹ nla ngbe soke ; nigbakigba li awa lè ṣegbé : Ẹṣu nfẹ egbé wa ainipẹkun, aiye sì ndẹkùn silẹ fun wa, awọn ifẹkufẹ ara wa sì nwá lati làn wa, ìwa buburu wa sì nfà wa lọ, awọn apẹrẹ iṣẹ buburu si mbà wa li ọkàn jẹ. Nitorinâ fi apa rẹ alagbara dâbobo wa, ki o ṣe itọju igbalà wa lârin ewu, ki o sì duro tì wa nigbagbogbo, lai máṣe mu oju rẹ kuro lọdọ wa.

L'oni ọkàn wa jẹ onitara gbigbona fun ìwa rere, ṣugbọn bi iwọ kò ba tọju wa, ti iwọ kò ba sì pa wa mọ ni mimọ, a tún lè di onitara gbigbona fun ìwa buburu ati èṣẹ.

Nitorinâ ninu idanwò wa, jẹ âbo wa ; ninu ailera wa jẹ ifẹhintì wa ; ninu ibanujẹ wa jẹ olutùnu wa ; ninu iyemeji wa jẹ imọlẹ wa, ati li ọna irìn wa jẹ amọna wa. Nikẹhin máṣe jẹ ki ọkan ninu wa ki o ṣina, ki o sì ṣubu si ọwọ èṣu, ṣugbọn jẹ ki gbogbo wa ki o lè de ibi isimi ati alafia ainipẹkun. Amin.

OPIN

VERBI
LEIÇARRAGANI
DICTIONARIOLVM
TOPOTHETICVM

LEICARRAGAREN
ERASKITZAKO
EDO
ADITZACO
HITZTEGICHO
BAT

TO THE MEMORY

OF MY MOTHERS KINSMEN

SIR NASH GROSE AND JOSIAH FORSHALL

CONCORDANCE to the 219 forms of the Verb employed in St Pauls Epistles to St Timothy, in Leiçarragas Basque version, anno Domini 1571.

Ac. 3. Impératif, s. 2e adr. masc : abréviation, aux. act.

2.1.13. EDUCac.. eguiazco formá, .. Retien le vrai patron

2.4.11. Marc HARTURIC EREKARRac eurequin :... Pren Marc & l'amene auec toy,

2.4.13 ... manteliná, ETHOR *adinean* EKARRac eurequin,... Quand tu viendras, apporte auec toy la manteline

ADI. 9. Impératif, s. 2e auxiliaire.

1.6.5... : RETIRa*di* halacoetaric... : retire-toy de ceux qui sont tels.

2.2.1. Hi bada, ene semé, FORTIFICa*di*... Toy donc, mon fils, sois fortifié

2.2.15. DILIGENTa*di* eure buruären laincoari APPROBATU PRESENTATZERA,... Fay diligence de te rendre approuué à Dieu,

2.3.5...: APPARTA *adi* bada hetaric..., destourne-toy donc d'iceux.

2.3.14. Bada hi EGON *adi*... Or toy, demeure

2.4.2...: ARI *adi* REDARGUITZEN, MEHATCHATZEN, EXHORTATZEN, ..., argue, tance, exhorte

2.4.9. DILIGENT*adi* enegana ETHORTERA sarri... Diligente-toy de venir bien tost à moy.

2.4.15 Harenganic hi-ere BEGUIR*adi* :... Duquel aussi garde-toy.

2.4.21. DILIGENT*adi* negu aitzinean ETHORTERA... Diligente-toy de venir deuant l'hyuer.

ADINÇÁT. 1. Subj. prés. s. 2e décl. destin. aux.

1.1.18.... heçaz BATAILLATZE onez BATAILLA *adinçát*:... , que... tu faces par icelles bon deuoir de guerroyer.

ADINEAN. 1. I. q. le précédent décliné au locatif de temps.

2.4.13.... ETHOR *adinean*... Quand tu viendras,

AIÇATE. 1. Ind. fut. s. 2e verbe subst. Inchauspe confirme ceci.

1.4.6... Iesus Christen ministre on AIÇATE,..., tu seras bon ministre de

EZAICELA. 1. Impératif, s. 2. aux. (synonyme de *Adi* et *Aicen*)

2.1.8. EZ*aiçela* bada AHALQUE gure Iaunaren testimoniageaz,... N'aye point donc de honte du tesmoignage de nostre Seigneur,

AICÉN. 1. Conj. (sens de l'impératif). prés. s. 2e verbe subst. & aux.

1.1.12... : baina AICEN fidelén exemplu hitzean, ... : mais sois patron des fideles en parole,

1.1.15..., *eta* AICÉN gauça hautan attento : ..., & y sois attentif,

2.1.8... : baina AICÉN participant... : mais sois participant

2.2.8. *Aicén* ORHOIT... Aye memoire

BAIT AIZ. 1. Ind. prés. s. 2e aux.

1.6.12..., ceinctera DEITHU-ere bait*aiz*,... à laquelle aussi tu es appelé

ANDIN. 1. Subj. passé s. 2e aux.

1.1.3... Ephesen EGON *andin*,... que tu demeurasses

Aqvié. 1. Impératif, s. 2e r. s. r. i. pl. aux. *(ekin)*.

1.6.11....eta IARREIQUI *aquié* iustitiari, pietateari, fedeari, charitateari, patientiari, emetassunari... & pourchasse iustice,

Aqvió. 3. Impér. s. 2e r. i. s. distributivement, verbe subst.

1.4.13. ., *aquió* IRACURTZEARI, EXHORTATZEARI, doctrinari... Sois attentif à la lecture, à exhortation, & à doctrine, (on a omis *attentif* dans le Basque).

1.6.12..., LOT *aquio* vicitze eternalari, ..., apprehende la vie eternelle,

2.2.22..., eta IARREIQUI *aquió* iustitiari, ..., & pourchasse iustice,

Atzayón. 1. Ind. prés. s. 2. r. i. s. *n* rel. accus. = *que*, aux.

1.4.6..., IIACI *içanic* fedearen, eta diligentqui IARREIQUI *atzayón* doctrina onaren hitzetan.... nourri és paroles de foy, & de bonne doctrine, que tu as songneusement suyuie.

Avt. 4. Ind. prés. s. 1e r. s. 2e pers. aux. act.

1.2.1. EXHORTATZEN *aut* bada... I'admonneste donc

1.5.21. REQUERITZEN *aut*... Ie t'adiure

2.1.6. Causa hunegatic AUISATZEN *aut*... Pour laquelle cause ie t'admonneste

2.4.1. REQUERITZEN *aut* bada nic... Ie t'adiure donc

Avté. 1. Ind. prés. pl. 3e r. s. 2e pers. aux. act.

2.4.21. SALUTATZEN *auté* Euboloc eta Pudensec eta Linoc eta Claudiac eta anaye guciéc... te saluent.

Beça. 1. Impératif, s. 3e r. s. aux. act.

1.2.11. Emazteac silentiorequin IKAS *beça*... Que la femme apprenne en silence,

Beçate. 1. Impératif, pl. 3. r. s. aux. act.

1.5.4..., IKAS *beçate* lehenic *berén* etche proprira pietateren ERACUSTEN, eta burhassoetara ordainaren RENDATZEN:..., qu'ils apprennent premierement à monstrer leur pieté enuers leur propre maison, & à rendre la pareille à leurs parens :

Bedi. 2. Impératif, s. 2e aux.

1.5.9. *Emazte* alharguna HAUTA *bedi* ez hiruroguey vrthe baino gutiagotacoa, senhar baten emazte *içana* : ... La vefue soit enrolee n'ayant point moins de soixante ans, qui ait esté femme d'vn mari :

2.2.19... eta, RETIRA *bedi* iniustitiataric ... se retire d'iniquité.

Bitez. 1. Impératif, pl. 3e aux.

1.5.17... Ancianoac ohore doblaren digne ESTIMA *bitez* : ... Les Anciens... soyent reputez dignes de double honneur,

Bitza. 1. Impératif, s. 3e r. pluriel, aux. act.

1.5.16..., AIUTA *bitza* hec,... qu'il leur subuienne,

Bitzate. 2. Impératif, pl. 3e r. pl. aux. act.

1.6.1..., bere nabussiac ohore ororen digne ESTIMA *bitzate* : ... Que tous... estiment leurs maistres dignes de tout honneur :

1.6.2... baina aitzitic CERBITZA *bitzate*, ..., ains plustost qu'ils les servent

Çaicvn. 1. Ind. prés. s. 3e r. i. pl. 1e pers. aux. *n* rel. nomin.

2.1.9. . Iesus Christ baithan EMAN *içan çaicun* gratiaren causaz ... par ... & grace laquelle nous est donnee en Iesus Christ

Çaitadanaren. 1. Ind. prés. s. 3e r. i. s. 1e pers. avec *ada* euphonique, & *n* rel. décliné au génitif, aux.

1.1.11.... Euangelio gloriazco niri cargutan EMAN *içan çaitadanaren* araura ... selon l'Euangile de la gloire... lequel *Euangile* m'est commis.

Çaizqvián. 1. Ind. prés. pl, 3e r. i. s. 2e pers. *n* rel. pl. = *qui* (*á* remplace un *k* élidé.) aux. adr. masc.

2.3.14... eta EMAN *içan çaizquián* gaucetan, ..., & desquelles pleine asseurance t'a esté donnee, (ici Leiçarraga ne serre pas le texte français).

Çaizqvianac. 1. I. q. préc. *n* relatif decliné à l'accusatif pluriel, régime de *dituc* sous-entendu avec *saluaturen*.

1.4.16... eta hiri BEHATZEN *çaizquianac*... & ceux qui l'escoutent.

ÇAIZTELA. 1. Ind. prés. pl. 3. r. i. pl. term. particip. *la*, aux.

1.4.1... spiritu abusariey BEHATZEN *çaiztela*,... s'amusans aux esprits abuseurs, *(s'amusans* ne traduit pas *behatzen)*

ÇAYELA. 1. Ind. prés. s. 3. r. i. pl. *la* conjonctif, aux.

1.3.16.... PREDICATU *içan çayela* Gentiley,.... presché aux Gentils,

ÇAYONEZ. 1. Ind. prés. s. 3. r. i. s. *n* conj. décl. au médiatif en supplément de *eya* = *utrum*; auxiliaire.

1.5.10..., eya obra on orori ardura IARREIQUI *içan çayonez*, ... si elle a songneusement suyui toute bonne œuure.

BACEAQVIAGV. 1. Ind. prés. pl. 1e r. s. verbe irrég. *iaquin*. adr. masc Synonyme de *badaquiagu* selon Inchauspe.

1.1.8. Eta BACEAQUIAGU ecen .. Or nous sçauons que...

BACEAQVIAT 1. Ind. prés s. 1e r. s. verbe irrég. *iaquin*. adr. masc. Synonyme de *badaquiat* selon Inchauspe. Ce vénérable Boscophile en parlant de ce mot et du précédent m'a écrit « encore aujourd'hui une forme est employée pour l'autre indifféremment en Soule ».

2.1.12...: ecen *baceaquiat*...: car ie sçay...

CEÇAQVEC. 1. Pot. prés. s. 3e r. s. aux. act. adr. masc.

2.2.13..., VKA bere buruã EGIN *ceçaquec*..., il ne se peut renier soy mesme.

CELARIC. 1. Ind. imparf. s. 3. *n* élidé par la terminaison participiale partitive, *laric*. verbe substantif.

2.2.8..., Dauid - en hacitic CELARIC.... *estant* de la semence de Dauid,

CENEAN. 1. I. q. le préc décl. locatif de temps. aux.

2.4. (Colophon)... SCRIBATU, Paul berriz Cesar Neronen aitzinean PRESENTATU *içan cenean*... Escrite..., quand Paul fut derechef presenté à Cesar Neron.

CIAITADAC. 3. Ind. prés. s. 3e r i. s. 1e pers. adr. masc. aux.

1.1.13... baina misericordia EGUIN *içan ciaitadac*:... mais misericorde m'a esté faite,

1.1.16. Baina hunegatic misericordia EGUIN *içan ciaitadac*, ... Mais pour ceste cause misericorde m'a esté faite :

2.4.17. Baina Iauna ASSISTITU *içan ciaitadac*,... Mais le Seigneur m'a assisté

CIAIZTEC. 1. Ind. prés. pl. 3e r. i. pl. adr. masc. aux.

1.5.24...: eta batzuey ondoan-ere IARREIQUITEN *ciaiztec*..., mais ils suyuent apres eu d'autres.

CIOAT. 2. Ind. prés. s. 1e r. s. verbe irrég. act. *erran* adr. masc.

1.2.7. (eguia CIOAT Christean... (ie di verité en Christ:

2.3.11... CIOAT, ..., *di-ie*,

CITIÁT. 1. Ind. prés. s. 1e r. pl. adr. masc. aux. act.

2.2.10. Halacotz gauça guciac SUFFRITZEN *citiát* ELEGITUACGATIC,... Pour ceste cause, ie souffre tout pour l'amour des eleus,

ÇVTELARIC. 1. Ind. imparf. pl. 3e r. s. term. participiale partitive, aux. act.

1.6.21. Cein *scientiaz* professione EGUITEN *çutelaric*... De laquelle aucuns faisans profession

ÇVTENÉN. 1. Ind. imparf. pl. 3e r. s. *n* rel. décl. génit. aux. act.

1.1.16... hura baithan vicitze eternaleracotzat SINHETSIREN *çutenén*... à ceux qui viendroyent à croire en luy à vie eternelle.

DA. 4. Ind. prés. s. 3e verbe subst. et aux.

1.1.10..., eta baldin deus berceric doctrina sanoaren contratacoric BADA... & s'il y a quelque autre chose qui soit contraire à la

1.4.4..., baldin remerciamendurequin RECEBITZEN *bada* ... quand il est pris auec

1.5.18. Eta, Languilea bere sariaren *digne* DA..., & L'ouvrier est digne de son salaire.

2.2.5... baldin bidezqui COMBATITU *ezpada*... s'il n'a combatu deuëment.

DADASSATELARIC. 1. Ind. prés. pl. 3e term. participiale partitive, verbe irr. ERASTEN.

1.5.13... gaucéz DADASSATELARIC..., en babillant des choses

badadi. 1. Hypothétique. prés. s. 3e aux.

1.2.15..., baldin EGON b*adadi* fedean, ..., si elle demeure en foy

Dadin. 1. Subj. prés. s. 3e aux.

1.4.9..., eta guciz RECEBI *dadin* dignea..., & digne d'estre entierement recueë.

Dadinçát. 2. I. q. préc. décl. destinatif.

2.3.17. Compli *dadinçát* laincoaren guiçona, obra on orotara complituqui INSTRUITURIC... A fin que l'homme de Dieu soit accompli, appareillé à toute bonne œuure.

2.4.17..., niçaz predicationea COMPLI *dadinçát*, ..., à fin que la predication fust rendue approuuee par moy

Dadvtzatenac. 1. Selon Inchauspe une contraction de IDUQUITEN *dituztenac*. Nominatif intransitif, sujet de *dituc*. Voyez dituztenéc

2.3.6..., eta gathibu DADUTZATENAC emazteto bekatuz CARGATUAC, guthicia diuersez ERABILIAC,... & qui tiennent captives les femmelettes chargees de pechez, menees par diuers desirs.

Dagoten. 1. Ind prés. s. 3. r. i. pl. *n* conj. verbe irrég. *egon*.

1.2.10... EGUITEN *duteney* DAGOTEN beçala) obra onez. (qui est chose conuenable à femmes qui font

badagvic. 1. Ind. prés. s. 2e r. s adr. masc. verbe irrég. actif *eguin*.

1.4.16...: ecen baldin haur b*adaguic*,...: car en ce faisant

Dagviola. 1. Impér. (opt.) s. 3e r. s r. i. s. verbe irr. *eguin*.

2.1.16. Iaunac misericordia DAGUIOLA Onesiphoren etcheari:... Le Seigneur doint misericorde à la maison Confer. *Llibre del Roser*. (Barcelona 1679) *Advertencia*, « Y per donarli gracias de la misericordia nos feu en dita Batalla Naval, y demés mercès, y gracias nos fa cada dia.» & p. 235 « pregantlos quem agen gracia ». Fléchier dans

l'Oraison Funèbre de Mᵉ de Montausier dit « Je veux retracer dans vostre memoire les graces que Dieu luy a faites, afin que vous louiez la misericorde qu'il vient de luy faire ». L'Anglais dit « do me the favour, pleasure ».

DAGVITEN. 2. Subj. prés. pl. 3ᵉ r. s. verbe irrég. *eguin*

1.2.8... guiçonéc othoitz DAGUITEN leku orotan... que les hommes facent priere en tout lieu,

1.5.14..., haour DAGUITEN, ..., qu'elles procreent lignee,

DAITEN. 1. Pot. prés s. 3ᵉ *n* rel. = *à laquelle.* aux.

1.6.16..., nehor HURBIL ECIN *daiten* arguian ... en vne lumiere inaccessible,

DAITEZQVEC. 1. Pot. prés. pl. 3ᵉ adr. masc. aux.

1.5.25..., ecin ESTAL *daitezquec* ..., ne peuuent estre cachees.

DAITEZQVELARIC. 1. Pot. prés. pl. 3ᵉ aux. term. partic. part. *laric.*

2.3.7..., eta behinere eguiaren EÇAGUTZERA HEL ECIN *daitezquelaric*..., & iamais ne peuuent venir à la cognoissance de verité.

ezpa DAQVI. 1. Ind. prés. s. 3ᵉ r. s. verbe irrég. act, *iaquin.*

1.3.5. (Ecen baldin edoceinec bere etchearen GOBERNATZEN ezpaDAQUI, ... car si quelqu'un ne sçait conduire son mesnage,

DAQVIALARIC. 2. Ind. prés. s. 2ᵉ r. s. adr. masc. term. partic. partit. *laric* précédée de l'a euphonique qui remplace c. comme en *daquiançát* verbe irrég. *iaquin.*

2.2.23.... DAQUIALARIC ecen..., sçachant qu'elles

2.3.14..., DAQUIALARIC..., cognoissant de qui

DAQVIANÇÁT. 1. Subj. prés, s. 2ᵉ r. s. décl. destin. adr. masc. (selon Inchauspe) verbe irrég. actif *iaquin.*

1.3.15..., DAQUIANÇ*át* nola... A fin que tu sçaches ... comment

baDAQVIC. 2. Ind. prés. s. 2ᵉ r. s. adr. masc. verbe irr. *iaquin.*

2.1.15. BADAQUIC haur,... Tu sçais que

2.1.18..., hic guciz vngui DAQUIC..., tu le cognois tres bien.

Daqvigvlaric. 1. Ind. prés. pl. 1e r. s. term. partic. partit. verbe irrég. *iaquin*.

1.1.9. Daquigularic ecen... Sçachans que

badeça. 1. Hypothétique prés. s. 3e r. s. aux. act.

